IWE

ADURA YORUBA,

ATI TI IṢẸ-IRANṢẸ

AWỌN SACRAMENTI,

TI O SÌ NI

ILANA MĬ ATI ISÌN-ILANA,

PẸLU

AWỌN PSALMU TI DAFIDI.

LONDON:
SOCIETY FOR PROMOTING CHRISTIAN KNOWLEDGE;
NORTHUMBERLAND AVENUE, CHARING CROSS;
4, ROYAL EXCHANGE; 48, PICCADILLY.

Digitized by Google

ADURA YORUBA.

ADURA OWURO.

ỌRỌ NINU IWE ỌLỌRUN.

NIGBATI enia buburu ba yipada kuro ninu ìwa buburu rẹ̀ ti o ti nhù, ti o sì ṣe eyi ti õtọ, yio gbà ọkkàn rẹ̀ là lãye. *Esek.* 18. 27.

Mo jẹwọ irekọja mi: nigba-gbogbo li ẹ̀ṣẹ̀ mi sì mbẹ niwaju mi. *Psal.* 51. 3.

Pa oju rẹ mọ́ kuro lara ẹ̀ṣẹ̀ mi, ki iwọ ki o sì nù gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ mi nù kuro. *Psal.* 51. 9.

Ẹbọ Ọlọrun ni irobinujẹ ọkkàn: irobinujẹ ati irora àiya, Ọlọrun, on ni iwọ kì yio gàn. *Psal.* 51. 17.

Fà àiya nyin ya, kì iṣe aṣọ nyin, ki ẹnyin ki o sì yipada si JEHOFA Ọlọrun nyin: nitori ti o pọ̀ li ore-ọfẹ, o sì kún fu ãnu, kì ibinu kankan, o ṣeun pipọ̀, o sì ronupiwada ati ṣe buburu. *Joeli* 2. 13.

Ti Oluwa Ọlọrun wa li ãnu ati idariji, bi awa tilẹ ṣọ̀tẹ̀ si i, ti awa kò sì gbà ohùn JEHOFA Ọlọrun wa gbọ́, lati ma rìn nipa ofin ti o gbé kalẹ niwaju wa. *Dan.* 9. 9, 10.

JEHOFA, kìlọ fu mi, ṣugbọn ni ibawi ni, ki o máṣe ni ibinu rẹ, ki iwọ ki o má sọ mi dasan. *Jeremia* 10. 24.

Digitized by Google

Ẹnyin ronupiwada; nitori ti ijọbba ọrun kùn si dèdẹ. *Mat.* 3. 2.

Emi o dide sẹ́, emi o tọ̀ babba mi lọ, emi o sì wi fu u pe, Babba, emi ti ndẹṣẹ si ọrun, ati niwaju rẹ, emi kò sì yẹ ti a ba ma pè li ọmmọkọnri rẹ, mọ́. *Luk.* 15. 18, 19.

JEHOFA, má ba ọmmọ ọdọ rẹ lọ sinu idajọ́; nitori ti kò si ẹniti o wà lãye ti a o dalare niwaju rẹ. *Psal.* 143. 2.

Bi awa ba wipe, awa kò li èṣẹ awa tàn ara wa jẹ, otitọ kò sì si ninu wa: ṣugbọn bi awa ba jẹwọ èṣẹ wa, olõtọ ati olododo li on lati dari èṣẹ wa jì wa, ati lati wẹ̀ wa nù ninu àìṣododo gbogbo. 1 *Joh.* 1. 8, 9.

ẸNYIN ara olufẹ ọwọn, Iwe Ọlọrun ni mu wa ni ibi pipọ̀ ninu rẹ̀ lati jẹwọ ọpọlọpọ èṣẹ on ìwa buburu wa làìṣẹ̀tan, ati lalbo èṣẹ wa mọlẹ niwaju Ọlọrun Olodumare Babba wa ti mbẹ li ọrun; ṣugbọn ki awa ki o fi irẹlẹ, iparamọ, ironupiwada, ati igboran si àiya jẹwọ wọn; nitori idi ọkan yi ni, ki awa ki o le ri idariji èṣẹ wa gbà, nitori ore ati ãnu rẹ̀ ti kò nipẹkun. Bi awa tilẹ mọ̀ pe o yẹ pe awa iba ma fi iparamọ jẹwọ èṣẹ wa nigba-gbogbo niwaju Ọlọrun; ṣugbọn o yẹ ki awa ki o ṣe bẹ̃ julọ, nigbati awa ba pade ti awa ba pejọ, ki awa ki o dupẹ fu u nitori ore pipọ̀ ti awa ti ngbà li ọwọ́ rẹ̀, ki awa ki o rò iyìn rẹ̀ ti o yẹ julọ, ki awa ki o gbọ́ Ọrọ rẹ̀ ti o mọ́ julọ, ki awa ki o sì tọrọ nkan wọn-ni lọwọ́ rẹ̀, ti awa kò le ṣe làìni, fu ara wa ati fu ọkkàn wa pẹlu. Njẹ nitori na, mo bẹ̀ iwọn ẹnyin ti o wà nihinyi nisisiyi, ki ẹnyin ki o fi mimọ́ àiya, ati irẹlẹ ohùn, ba mi lọ si idi itẹ́ ti ore-ọfẹ ọrun, ẹ ma wi lẹhin mi.

Digitized by Google

ADURA OWURỌ.

IJẸWỌ TI AWỌN ENIA GBOGBO.

OLODUMARE Babba alãnu julọ; Awa ti yapa, awa sì ti ṣìna kirikiri kuro li ọna rẹ bi agutan ti o nù. Awa ti ntọ ipa idamọran ati ifẹ inu wa jọjọ. Awa ti ṣẹ si ofin rẹ mimọ. Awa ti fi nkan wọn-ni ti a ba ṣe silẹ lalṣe; Awa sì ti ṣe nkan wọn-ni ti a ba fi silẹ lalṣe; Ilera kò sì si ninu wa. Ṣugbọn iwọ, Oluwa, ṣãnu fu wa òtoṣi ẹlẹṣẹ. Ọlọrun, iwọ da awọn ti o jẹwọ èṣẹ wọn silẹ. Mu awọn ti o ronupiwada sipò; Gẹgẹ bi ileri ti iwọ ṣe fu araiye lara Kristi Jesu Oluwa wa. Fi fu wa, Babba alãnu julọ, nitori rẹ; Ki awa ki o le ma gbé lati isisiyi lọ, bi-Ọlọrun, lalẹṣẹ, ati gbé aiye alrekọja, si ogo orukọ rẹ òwọ. Amin.

IFIJI ÈṢẸ.

OLỌRUN Olodumare. Babba Jesu Kristi Oluwa wa, ẹniti kò fẹ ikú ẹlẹṣẹ, bikoṣepe ki o kuku yipada kuro ninu ìwa buburu rẹ, ki o sì yè; ẹniti o sì ti fi agbara ati aṣẹ fu awọn Alufa rẹ, lati rò fu wọn ati lati sọ ti Ifiji ati Imukuro èṣẹ fu awọn enia rẹ, ti o ronupiwada! O darijì o sì fi èṣẹ jì gbogbo awọn ti o ronupiwada nitõtọ, ti o sì fi alṣẹtan gbà Ihin-rere mimọ rẹ gbọ. Njẹ nitori na ẹ jẹ ki awa ki o bẹbẹ lọdọ rẹ, ki o le fi ironupiwada tõtọ, ati Ẹmmí Mimọ rẹ fu wa, ki ohun gbogbo ti awa nṣe nisisiyi ki o le ma wù u; ati aiye wa iyokù lẹhin eyiyi, ki o le ma wà li allẽri, ati ni mimọ ìwa; tobẽ nigbẹhin ki awa ki o le de ibi ayọ rẹ ti kò nipẹkun; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. Amin.

ADURA OLUWA.

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọwọ li orukọ rẹ. Ijọba rẹ de. Ifẹ ti rẹ ni ki a ṣe li

Digitized by Google

aiye, Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ọjọ wa loni. Dari ẹṣẹ wa jì wa, Bi a ti ndari ẹṣẹ jì awọn ti o ṣẹ wa. Má fà wa sinu idẹwò; Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin: Nitori ijọba ni ti rẹ, agbara ni ti rẹ, ogo ni ti rẹ, lailai. Amin.

Alufa. Oluwa, iwọ ṣí wa li ète.

Idahun. Ẹnu wa yio sì ma fi iyìn rẹ hàn.

Alufa. Ọlọrun, ṣíṣẹ ki o gbà wa là.

Idahun. Oluwa, yara ki o ràn wa lọwọ.

Dide duro.

Alufa. Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí Mimọ;

Idahun. Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẹ̀ni yio sì ma ri nigba-gbogbo: aiye àìnipẹkun. Amin.

Alufa. Ẹ yìn Oluwa.

Idahun. Orukọ Oluwa ni ki a fi iyìn fu.

ORIN SI JEHOFA.

Psalmu 95.

ẸNYIN wá, ẹ jẹ ki a kọnrin si JEHOFA: ẹ jẹ ki a hó ihó ayọ̀ si Apatta igbala wa.

Ẹnyin jẹ ki a fi ọpẹ́ wá si iwaju rẹ̀: ki a sì fi orin mimọ́ hó ihó ayọ̀ si ọdọ rẹ̀.

Nitori JEHOFA Ọlọrun ti o tobi ni: at Ọbba ti o tobi jù gbogbo ọlọrun lọ.

Ni ikawọ ẹniti ibi ọ̀gbọn ilẹ wà: agbara òke giga ni ti rẹ̀ pẹlu.

Ti rẹ̀ li okun, on li o sì da a: ọwọ́ rẹ̀ li o sì da iyangbẹ ilẹ.

Ẹnyin wá, ẹ jẹ ki a wolẹ, ki a tẹriba: ẹ jẹ ki a kunlẹ niwaju JEHOFA Ẹlẹda wa.

Nitori on li Ọlọrun wa: awa sì li enia papa rẹ̀, ati agutan ọwọ́ rẹ̀.

Digitized by Google

Loni, bi ẹnyin ba nfẹ gbọ́ ohùn rẹ̀, ẹ má sé àiya nyin le: bi igba imunibinu, ati bi ọjọ idanwò li aganjù;

Nigbati awọn babba nyin dan mi wò: ti nwọn mọ̀ mi, ti nwọn sì ri iṣẹ́ mi.

Li ogoji ọdún tọ̀tọ ni inu mi fi bajẹ si iran yi, mo ni: Enia li o nṣìna li àiya wọn, nwọn kò sì mọ̀ ipa ọ̀na mi.

Awọn ẹniti mo sì bura fu ni ibinu mi pe: nwọn kì yio sì wọ̀ ibi isimi mi.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí Mimọ́;

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ̀ nisisiyi, bẹ̃ni yio sì ma ri nigba-gbogbo: aiye alnipẹkun. Amin.

ÌYÌN SI ỌLỌRUN.

AWA nyìn ọ, Ọlọrun: awa njẹwọ rẹ̀ pe iwọ li Oluwa.

Gbogbo aiye fi ori balẹ fu ọ: Babba aiye titi lai.

Iwọ li ẹniti gbogbo awọn Àngeli nkigbe pè: Ọrun, ati gbogbo Agbara ti mbẹ̀ ninu wọn.

Iwọ li ẹniti awọn Kerubu, ati awọn Serafu: nkigbe pè nigba-gbogbo pe,

Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́: Oluwa Ọlọrun awọn ọmmọ ogun;

Ọrun on aiye kún fu Ọlla-nla: ti Ogo rẹ̀.

Ẹgbẹ awọn Aposteli ti o li ogo: nyìn ọ.

Ọgba awọn Woli ti o dara: nyìn ọ.

Ogun awọn Ajẹrikú ti o li ọlá: nyìn ọ.

Ijọ mimọ́ ti awọn enia Ọlọrun ni gbogbo aiye: njẹwọ rẹ̀;

Babba: ẹni Ọlla-nla ti kò nipẹkun;

Ati Ọmmọ rẹ̀ nikanṣoṣo: ọlọ́lá, olõtọ;

Ẹmmí Mimọ́ pẹlu: Olutunu.

Kristi: iwọ li Ọbba Ogo.

Digitized by Google

Iwọ li Ọmmọ lailai: ti Babba.

Nigbati iwọ tẹwọgbà a fu ara rẹ lati gbà enia là: iwọ kò korira inu Wundia.

Nigbati iwọ ṣẹgun nimu ikú tan: iwọ ṣí Ijọbba Ọrun silẹ fu gbogbo awọn onigbagbọ.

Iwọ joko li ọwọ ọtún Ọlọrun: ninu Ogo ti Babba.

Awa gbagbọ pe iwọ mbọwá: lati ṣe Onidajọ wa.

Nitori na li awa ṣe ngbadura si ọdọ rẹ, ràn awọn ọmmọ ọdọ rẹ lọwọ: ti iwọ ti fi ẹjẹ rẹ iyebiye rà pada.

Ṣe wọn lati kà wọn kún awọn Enia mimọ rẹ: ninu ogo ti kò nipẹkun.

Oluwa, gbà awọn enia rẹ là: ki iwọ ki o sì fi ibukún fu awọn enia ini rẹ.

Jọbba wọn: ki iwọ ki o sì ma gbé wọn soke lailai.

Awa ngbé iwọ ga: lojojumọ;

Awa sì nfi ori balẹ li Orukọ rẹ: titi aiye ti kò nipẹkun.

Fiyesini, Oluwa: lati pa wa mọ loni li alleṣẹ.

Oluwa, ṣãnu fu wa: ṣãnu fu wa.

Oluwa, jẹ ki ãnu rẹ ki o ma bà le wa: gẹgẹ bi awa ti ngbẹkẹ wa le ọ.

Oluwa, iwọ ni mo gbẹkẹle: lai má jẹ ki emi damu.

OLUBUKÚN.

Luku 1. 68.

OLUBUKÚN li Oluwa Ọlọrun Israeli: nitori ti o ti bojuwò, ti o sì ti da awọn enia rẹ ni ìde;

Ti o sì ti gbé iwo igbala soke fu wa: ni ile Dafidi ọmmọ ọdọ rẹ:

Digitized by Google

Bi o ti wi li ẹnu awọn woli rẹ mimọ́: ti nwọn ti mbẹ nigbati aiye ti ṣẹ:

Pe a o gbà wa là lọwọ́ awọn ọtá wa: ati lọwọ́ gbogbo awọn ti o korira wa;

Lati ṣe ãnu ti o ti leri fu awọn babba wa: ati lati ranti majẹmu rẹ mimọ́;

Ara ti o ti bu fu Abrahamu babba wa: pe on o fifu wa;

Lati gbà wa lọwọ́ awọn ọtá wa: ki awa ki o le ma sìn i li alfoya;

Ni mimọ́ ìwa ati li ododo niwaju rẹ: li ọjọ aiye wa gbogbo.

Ati iwọ, Ọmmọ, Woli Ọga-ogo li a o ma pè ọ: nitori iwọ ni yio ṣaju Oluwa lati tún ọ̀na rẹ ṣe;

Lati fi ìmọ igbala fu awọn enia rẹ: fu imukuro ẹ̀ṣẹ wọn,

Nipa iyọnu Ọlọrun wa: nipa eyi ti ìla-õrùn lati oke wá bojuwò wa;

Lati fi imọlẹ fu awọn ti o joko li òkunkun, ati ninu ojiji ikú: ati lati fi ẹsẹ wa le ọ̀na alafia.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí Mimọ́;

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẹ̃ni yio sì ma ri nigba-gbogbo: aiye alnipẹkun. Amin.

ORIN AYỌ̀ SI JEHOFA.

Psalmu 100.

EHÓ ihó ayọ̀ si JEHOFA, ẹnyin ilẹ gbogbo: ẹ fi ayọ̀ sìn JEHOFA: ẹ wá ti ẹnyin ti orin si iwaju rẹ.

Ki ẹnyin ki o sì mọ̀ pe JEHOFA on li Ọlọrun: on li o da wa, kì iṣe awa tikara wa; awa li enia rẹ, ati agutan papa rẹ.

Ẹ lọ si ẹnu ọ̀na rẹ ti ẹnyin ti ọpẹ́, ati si afin

Digitized by Google

rẹ ti ẹnyin ti iyìn: ẹ ma dupẹ fu u, ki ẹ sì ma fi ibukún fu Orukọ rẹ.

Nitori ti JEHOFA pọ̀ li ore, ãnu rẹ̀ kò nipẹkun: ati otitọ rẹ̀ lati iran-diran.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí Mimọ́;

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẹ̃ni yio sì ma ri nigba-gbogbo: aiye aìnipẹkun. Amin.

IGBAGBỌ́.

MO gbà Ọlọrun Babba Olodumare gbọ́, Ẹlẹda ọrun on aiye:

Mo gbà Jesu Kristi gbọ́, Ọmmọ rẹ̀ kanṣoṣo Oluwa wa, Ẹniti a fi Ẹmmí Mimọ́ lóyun, Ẹniti a bí ninu Maria Wundia, Ẹniti o jìya lọwọ́ Pontiu Pilatu, Ẹniti a kàn mọ́ agbelebu, Ẹniti o kú, ti a sì sin, O ṣọkalẹ rè ipò okú; Ni ijọ ẹkẹta o tún jinde kuro ninu okú, O rè oke ọrun, O sì joko li ọwọ́ ọtún Ọlọrun Babba Olodumare; Nibẹ̀ ni yio gbé ti pada wá lati ba ãye on okú wijọ.

Mo gbà Ẹmmí Mimọ́ gbọ́; Ati Ijọ mimọ́ ti awọn enia Ọlọrun; Ati Idapọ ti awọn Enia mimọ́; Idariji ẹ̀ṣẹ̀; Ajinde ara ni isà okú, Ati ìye ti kò nipẹkun. Amin.

Alufa. Ki Oluwa ki o pẹlu nyin.

Idahun. Ki o sì pẹlu ẹmmí rẹ.

Alufa. Ẹ jẹ ki a gbadura.

Oluwa, ṣãnu fu wa.

Idahun. Kristi ṣãnu fu wa.

Alufa. Oluwa ṣãnu fu wa.

ADURA OLUWA.

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọ̀wọ li orukọ rẹ. Ijọba rẹ de. Ifẹ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye. Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ọjọ wa loni. Dari ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wa, Bi a ti ndari ẹ̀ṣẹ̀ jì

Digitized by Google

awọn ti o ṣẹ wa. Má fà wa sinu idẹwò ; Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin. *Amin.*

Alufa. Oluwa, fi ãnu rẹ hàn fu wa.

Idahun. Ki iwọ ki o sì fu wa ni igbala rẹ.

Alufa. Oluwa, gbà Ọbba là.

Idahun. Ki iwọ ki o sì fi ãnu gbó ti wa, nigbati awa ba npè orukọ rẹ.

Alufa. Fi ododo wọ awọn Alufa rẹ.

Idahun. Ki iwọ ki o sì fu awọn enia ayanfẹ rẹ li ayọ.

Alufa. Oluwa, gbà awọn enia rẹ là.

Idahun. Ki iwọ ki o sì bukún u fu ilẹ-ini rẹ.

Alufa. Fu wa li alafia ni igba ti wa, Oluwa.

Idahun. Nitori ti kò si ẹlomĩ ti ngbija wa, bikoṣe iwọ nikanṣoṣo, Ọlọrun.

Alufa. Ṣe àiya wa ki o di mimó ninu wa, Ọlọrun.

Idahun. Ki iwọ ki o sì má gbà Ẹmmí Mimó rẹ lọwó wa.

ADURA EKEJI, FU ALAFIA.

OLỌRUN, iwọ ti ṣe olorisọn alafia ati olufẹ irẹpọ, ni ìmọ ẹniti ẹmmí wa alnipẹkun gbé duro, ati sisìn ẹniti ṣe inira anitan; Dãbobo wa awọn oniparamọ ọmmọ ọdọ rẹ, ni gbogbo ikọlù awọn ọtá wa; bi awa ti ngbẹkẹle àbo rẹ gidigidi, ki awa ki o má bèru agbara ọtá-kọta, nitori agbara Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

ADURA ẸKẸTA, FU ORE-ỌFẸ.

OLUWA, Babba wa ti mbẹ li ọrun, Olodumare ati aiye-raiye Ọlọrun, iwọ ti o fi alafia mu wa de owurọ ọjọ oni ; Fi agbara rẹ nla dãbobo wa ninu rẹ na, ki iwọ ki o sì fifu wa,

Digitized by Google

ki a má ṣubu sinu ẹ̀ṣẹ́ loni, ati ki a má sûre wọ̀ inu ewu-kewu; ṣugbọn ki gbogbo ṣiṣẹ wa ki o le ti ọdọ iṣọ́ rẹ là lẹṣẹṣẹ wa, lati ṣe eyi ti o mọ́ li oju rẹ nigba-gbogbo; nitori ipa Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

ADURA FU ỌBBA.

OLUWA Babba wa ti mbẹ li ọrun, oloruko giga ati alagbara, Ọbba awọn ọbba, Oluwa awọn oluwa, iwọ nikanṣoṣo Oluṣọ awọn ọmmọ-alade, iwọ ti o nti ori itẹ́ rẹ wò gbogbo awọn araiye; Tọkkàn tọkkàn wa gidigidi li awa fi mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o fi oju ore-ọfẹ rẹ wò. N—Ọbba (Bãlẹ) wa. Fi ore-ọfẹ ti Ẹmmí Mimọ́ rẹ fu u, ki àiya rẹ̀ ki o le ma yipada nigba-gbogbo si ifẹ́ ti rẹ, ki o sì le ma rìn li ọ̀na rẹ: Fi ẹ̀bun rẹ ọrun fu u pipọ̀, ki o le ma tọju ọlá ati ogo re; Fu u ni ilera ati ilọrọ̀ ki on ki o gbó ki o tọ́ li aiye, ki o sì le ma jọbba awọn enia li ododo rẹ, ati ki o sì le ma pa wọn mọ́ li alafia; Kún ọ lọwọ́ ki o le lé ati ki o le ṣẹgun awọn ọtá rẹ̀ gbogbo; ati lẹhin aiye yi, ki o le de ibi ayọ̀ on ibukún rẹ ti kò nipẹ̀kun; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

ADURA FU IDILE ỌBBA, ATI AWỌN OLORI GBOGBO.

OLỌRUN Olodumare, Olorisọn ohun rere gbogbo; Alãbo gbogbo awọn ti o gbẹ̀kẹle ọ; Awa nfi irẹlẹ ohùn bẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o bukún u fu gbogbo idile Ọbba (Bãlẹ), awọn ìgbimọ, awọn olori, ati awọn balogun ilẹ yi gbogbo. Mu ohun ipalara gbogbo kuro lọdọ wọn, ki o sì fu wọn ni ilera, agbara ati alafia li ọjọ aiye wọn. Dãbobo wọn ninu gbogbo ewu ati ipọnju wọn. Fu wọn li ọgbọ́n ọrun, ati ma rò, on ati ma ṣe irú ohun

Digitized by Google

nwọn-ni ti o tọ́ li oju rẹ nigba-gbogbo. Fi ore-ọfẹ rẹ ọrun fu wọn ki nwọn ki o le gbà ọrọ mimọ́ rẹ gbọ́, ki nwọn ki o sì ni ìmọ otitọ ati igbala rẹ, lati ma mọ̀ iwọ ẹniti ṣe olugbala araiye, ati lati ma sìn ọ nitõtọ. Ọlọrun ninu ãnu rẹ nla pa wọn mọ́ lọdọ rẹ li aiye, ati lẹhin aiye yi ki o sì mu wọn wá si ijọba ọrun rẹ, nitori Jesu Kristi Oluwa wa. Amin.

ADURA FU AWỌN ALUFA ATI ENIA.

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, iwọ nikanṣoṣo ti o le ṣe ohun iyanu nla; Rán Ẹmmí ilera ti ore-ọfẹ rẹ silẹ si ori awọn Olori Alufa, ati si awọn Alufa wa, ati si gbogbo Ijọ awọn enia ti a fi si iṣọ́ wọn; nitõtọ ki nwọn ki o le ma ṣe bi yio ti wù ọ, ma da ìri ibukún rẹ si wọn nigba-gbogbo. Ọlọrun, fi eyi fu wọn, nitori ọlá Alagbawi ati Onilaja wa, Jesu Kristi. *Amin.*

ADURA TI KRISOSTOMU.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o ti fu wa ni ore-ọfẹ nisisiyi lati fi iye ṣe ọkkàn kan wa ìbẹbẹ lọdọ rẹ; iwọ sì ti ṣe ileri pe, nigbati ẹni meji tabi mẹta ba kó ara wọn jọ li Orukọ rẹ, iwọ o fi ìbere wọn fu wọn: Oluwa, mu iṣẹ́ inu ati ìbere awọn ọmmọ ọdọ rẹ ki o ṣẹ nisisiyi, bi yio ti le gbè fu wọn julọ; ma fi ìmọ otitọ rẹ fu wa li aiye yi, ati li aiye ti mbọ̀ lye aìnipẹkun. *Amin.*

2 Kor. 13. 14.

ORE-ỌFẸ Jesu Kristi Oluwa wa, ati ifẹ́ Ọlọrun, ati idapọ ti Ẹmmí Mimọ́, ki o ma ba gbogbo wa gbé sì i lailai. *Amin.*

Digitized by Google

ADURÀ ALẸ.

ỌRỌ NINU IWE ỌLỌRUN.

NIGBATI enia buburu ba yipada kuro ninu ìwa buburu rẹ̀ ti o ti nhù, ti o sì ṣe eyi ti õtọ́, yio gbà ọkkàn rẹ̀ là lãye. *Esek.* 18. 27.

Mo jẹwọ irekọja mi: nigba-gbogbo li èṣẹ mi si mbẹ niwaju mi. *Psal.* 57. 3.

Pa oju rẹ mọ́ kuro lara èṣẹ mi, ki iwọ ki o sì nù gbogbo èṣẹ mi nù kuro. *Psal.* 51. 9.

Ẹbọ Ọlọrun ni irobinujẹ ọkkàn: irobinujẹ ati irora àiya, Ọlọrun, on ni iwọ kì yio gàn. *Psal.* 51. 17.

Fà àiya nyin ya, kì iṣe aṣọ nyin, ki ẹnyin ki o sì yipada si JEHOFA Ọlọrun nyin: nitori ti o pọ̀ li ore-ọfẹ, o sì kún fu ãnu, kì ibinu kankan, o ṣeun pipọ̀ o sì ronupiwada ati ṣe buburu. *Joeli* 2. 13.

Ti Oluwa Ọlọrun wa lì ãnu ati idariji, bi awa tilẹ ṣọ̀tẹ̀ si i, ti awa kò sì gbà ohùn JEHOFA Ọlọrun wa gbọ́, lati ma rìn nipa ofin ti o gbé kalẹ niwaju wa. *Dan.* 9. 9, 10.

JEHOFA, kìlọ fu mi, ṣugbọn ni ibawi ni, ki o máṣe ni ibinu rẹ, ki iwọ ki o má sọ mi dasan. *Jeremia* 10. 24.

Ẹnyin ronupiwada; nitori ti ijọba ọrun kùn si dẹdẹ. *Mat.* 3. 2.

Emi o dide sọ́, emi o tọ̀ babba mi lọ, emi o sì wi fu u pe, Babba, emi ti ndẹṣẹ si ọrun, ati niwaju rẹ, emi kò sì yẹ ti a ba ma pè li ọmmọ-kọnri rẹ mọ́. *Luk.* 15. 18, 19.

JEHOFA, má ba ọmmọ ọdọ rẹ lọ sinu idajọ́; nitori ti kò si ẹniti o wà lãye ti a o dalare niwaju rẹ. *Psal.* 143. 2.

Digitized by Google

Bi awa ba wipe, awa kò li èṣẹ, awa tàn ara wa jẹ, otitọ kò sì si ninu wa: ṣugbọn bi awa ba jẹwọ èṣẹ wa, olõtọ ati olododo li on lati dari èṣẹ wa jì wa, ati lati wẹ wa nù ninu alṣodododo gbogbo. 1 *Joh.* 1. 8, 9.

ENYIN ara olufẹ ọwọn, Iwe Ọlọrun ni mu wa ni ibi pipọ ninu rẹ lati jẹwọ ọpọlọpọ èṣẹ on lwa buburu wa laìṣẹtan, ati laìbo èṣẹ wa mọlẹ niwaju Ọlọrun Olodumare Babba wa ti mbẹ li ọrun; ṣugbọn ki awa ki o fi irẹlẹ, iparamọ, ironupiwada, ati igboran si àiya jẹwọ wọn; nitori idi ọkan yi ni, ki awa ki o le ri idariji èṣẹ wa gbà, nitori ore ati ãnu rẹ ti kò nipẹkun. Bi awa tilẹ mọ pe o yẹ pe awa iba ma fi iparamọ jẹwọ èṣẹ wa nigba-gbogbo niwaju Ọlọrun; ṣugbọn o yẹ ki awa ki o ṣe bẽ julọ, nigbati awa ba pade ti awa ba pejọ, ki awa ki o dupẹ fu u nitori ore pipọ ti awa ti ngbà li ọwọ rẹ, ki awa ki o rò iyìn rẹ ti o yẹ julọ, ki awa ki o gbọ Ọrọ rẹ ti o mọ julọ, ki awa ki o sì tọrọ nkan wọn-ni lọwọ rẹ, ti awa kò le ṣe laìni, fu ara wa ati fu ọkkàn wa pẹlu. Nje nitori na, mo bẹ iwọn ẹnyin ti o wà nihinyi nisisiyi, ki ẹnyin ki o fi mimọ àiya ati irẹlẹ ohùn ba mi lọ si idi itẹ ti ore-ọfẹ ọrun, ẹ ma wi lẹhin mi.

IJẸWỌ TI AWỌN ENIA GBOGBO.

OLODUMARE Babba alãnu julọ; Awa ti yapa, awa sì ti ṣìna kirikiri kuro li ọna rẹ bi agutan ti o nù. Awa ti ntọ ipa idamọran ati ifẹ inu wa jọjọ. Awa ti ṣẹ si ofin rẹ mimọ. Awa ti fi nkan wọn-ni ti a ba ṣe silẹ laìṣe; Awa sì ti ṣe nkan wọn-ni ti a ba fi silẹ laìṣe; Ilera kò sì si ninu wa. Ṣugbọn iwọ, Oluwa, ṣãnu fu wa òtoṣi ẹlẹṣẹ. Ọlọrun, iwọ da awọn ti o jẹwọ èṣẹ wọn silẹ. Mu awọn ti o ronupiwada sipò; Gẹgẹ bi ileri ti iwọ ṣe fu

Digitized by Google

araiye lara Kristi Jesu Oluwa wa. Fi fu wa, Babba alãnu julọ, nitori rẹ; Ki awa ki o le ma gbé lati isisiyi lọ, bi-Ọlọrun, laìlẹṣẹ, ati gbé aiye alrekọja, si ogo orukọ rẹ ọwọ. Amin.

IFIJI ÈṢẸ.

OLORUN Olodumare, Babba Jesu Kristi Oluwa wa, ẹniti kò fẹ ikú ẹlẹṣẹ, bikoṣepe ki o kuku yipada kuro ninu ìwa buburu rẹ, ki o sì yè; ẹniti o sì ti fi agbara ati aṣẹ fu awọn Alufa rẹ, lati rò fu wọn ati lati sọ ti Ifiji ati Imukuro èṣẹ fu awọn enia rẹ, ti o ronupiwada: O dariji o sì fi èṣẹ jì gbogbo awọn ti o ronupiwada nitõtọ, ti o sì fi aìṣẹtan gbà Ihin-rere mimọ rẹ gbọ. Nje nitori na ẹ jẹ ki awa ki o bẹbẹ lọdọ rẹ, ki o le fi ironupiwada tõtọ ati Ẹmmí Mimọ rẹ fu wa, ki ohun gbogbo ti awa nṣe nisisiyi ki o le ma wù u; ati aiye wa iyokù lẹhin eyiyi, ki o le ma wà li aìlẽri, ati ni mimọ ìwa; tobẽ nigbẹhin ki awa ki o le de ibi ayọ rẹ ti kò nipẹkun; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. Amin.

ADURA OLUWA.

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọwọ li orukọ rẹ. Ijọba rẹ de. Ifẹ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ọjọ wa loni. Dari èṣẹ wa jì wa, Bi a ti ndari èṣẹ jì awọn ti o ṣẹ wa. Má fà wa sinu idẹwò; Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin. Nitori ijọba ni ti rẹ, agbara ni ti rẹ, ogo ni ti rẹ, lailai. Amin.

Alufa. Oluwa, iwọ ṣí wa li ète.

Idahun. Ẹnu wa yio sì ma fi iyìn rẹ hàn.

Alufa. Ọlọrun, ṣísẹ ki o gbà wa là.

Idahun. Oluwa, yara ki o ràn wa lọwọ.

Dide duro.

Alufa. Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ; ati fu Ẹmmí Mimọ;

Digitized by Google

Idahun. Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẹ̃ni yio sì ma ri nigba-gbogbo : aiye alnipẹkun. Amin.

Alufa. Ẹ yìn Oluwa.

Idahun. Orukọ Oluwa ni ki a fi iyìn fu.

IYÌN SI OLUWA.

Luku 1. 46—55.

ỌKKÀN mi yìn Oluwa logo : ẹmmí mi sì yọ̀ si Ọlọrun Olugbala mi.

Nitori ti o ṣiju-wò : ìwa irẹlẹ ti ọmmọbiri ọdọ rẹ̀.

Sá sì kiye si i, lati isisiyi lọ : gbogbo iran enia ni yio ma pè mi li alabukún fu.

Nitori ẹniti o lagbara ti ṣe ohun ti o tobi fu mi : ọ̀wọ sì li Orukọ rẹ̀.

Ãnu rẹ̀ sì mbẹ fu awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀ : lati iran-diran.

O ti fi agbara hàn li apa rẹ̀ : o ti tú awọn onirera ká ni ironu ọkkàn wọn.

O ti mu awọn alagbara kuro lori itẹ́ wọn : o sì gbé awọn talakà ati ọlọkkàn tutù soke.

O ti fi ohun ti o dara kún awọn ti ebi npa : o sì rán awọn ọlọrọ̀ pada li ọwọ́ ofo.

O ti ràn Israeli ọmmọ ọdọ rẹ̀ lọwọ́, ni iranti ãnu rẹ̀ : bi o ti sọ fu awọn babba wa, fu Abrahamu, ati fu irú-ọmmọ rẹ̀ lailai.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ : ati fu Ẹmmí Mimọ́ ;

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẹ̃ni yio sì ma ri nigba-gbogbo : aiye alnipẹkun. Amin.

ORIN TITUN SI JEHOFA.

Psalmu 98.

ẸNYIN kọn orin titun si JEHOFA : nitori ti o ti ṣe ohun iyanu.

Digitized by Google

Ọwọ́ ọtún rẹ̀, ati apa rẹ̀ mimọ́: on li o ti fi ṣẹgun fu ara rẹ̀.

JEHOFA ti fi igbala rẹ̀ hàn: ododo rẹ̀ li o ti fi hàn nigbangba li oju awọn keferi.

O ti ranti ãnu, ati otitọ rẹ̀ si awọn ara ile Israeli: gbogbo opin ilẹ̀ ti ri igbala Ọlọrun wa.

Ẹ hó ihó ayọ̀ si JEHOFA, ẹ hó yè, ẹ sì yọ̀: ki ẹ sì ma kọrin iyìn, gbogbo aiye.

Ẹ ma fi duru kọrin si JEHOFA: ati duru pẹlu ohùn orin mimọ́.

Pẹlu ìpe ati ohùn ifere: ẹ hó ihó ayọ̀ niwaju JEHOFA Ọba.

Jẹ ki okun ki o ma hó, pẹlu ikun rẹ̀: aiye ati gbogbo awọn ti mbẹ ninu wọn.

Jẹ ki odò ki o ma ṣápẹ, jẹ ki awọn òke ki o sì ma ṣe ajọ-yọ̀ niwaju JEHOFA: nitori ti o mbọ̀wá lati ṣe idajọ́ aiye.

Pẹlu ododo ni yio fi ṣe idajọ́ aiye: ati ti awọn enia li alṣegbe.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí Mimọ́;

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ̀ nisisiyi, bẹ̃ni yio sì ma ri nigba-gbogbo: aiye alnipẹkun. Amin.

IJỌWỌ LỌWỌ́ LỌ.

Luku 2. 29—32.

NISISIYI li o to jọwọ ọmmọ ọdọ rẹ̀ lọwọ́ lọ li alafia, Oluwa: gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ̀.

Nitori ti oju mi ti ri: igbala rẹ̀ na,

Ti iwọ ti pèse silẹ̀: niwaju awọn enia gbogbo;

Lati ṣe imọlẹ̀ ti yio mọlẹ̀ si awọn Keferi: ati lati ṣe ogo Israeli awọn enia rẹ̀.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí Mimọ́;

Digitized by Google

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẹ̀ni yio sì ma ri nigba-gbogbo : aiye alnipẹkun. Amin.

IṢẸ̄NU ỌLỌRUN.

Psalmu 67.

KI Ọlọrun ki o ṣãnu fu wa, ki o sì busi i fu wa : ki o sì ṣe oju rẹ̀ ki o mọlẹ si wa lara.

Ki ọ̀na rẹ̀ ki o le di mimọ̀ li aiye : ati igbala ilera rẹ̀ ni gbogbo orilẹ ède.

Jẹ̀ ki awọn enia ki o yìn ọ, Ọlọrun : jẹ̀ ki gbogbo awọn enia ki o yìn ọ.

Jẹ̀ ki inu awọn orilẹ ède ki o dùn, ki nwọn ki o sì ma kọnrin fu ayọ̀ : nitori ti iwọ o fi ododo ṣe idajọ́ awọn enia, iwọ o sì jọbba awọn orilẹ ède li aiye.

Jẹ̀ ki awọn enia ki o yìn ọ, Ọlọrun : jẹ̀ ki gbogbo awọn enia ki o yìn ọ.

Nigbana ni ilẹ yio to ma mu asọnkún rẹ̀ wá : Ọlọrun, Ọlọrun wa tikara rẹ̀, yio busi i fu wa.

Ọlọrun yio busi i fu wa : ati gbogbo opin aiye yio sì ma bẹ̀ru rẹ̀.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ : ati fu Ẹ̀mmí Mimọ́ ;

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẹ̀ni yio sì ma ri nigba-gbogbo : aiye alnipẹkun. Amin.

IGBAGBỌ́.

MO gbà Ọlọrun Babba Olodumare gbọ́, Ẹlẹda ọrun on aiye :

Mo gbà Jesu Kristi gbọ́, Ọmmọ rẹ̀ kanṣoṣo Oluwa wa, Ẹniti a fi Ẹ̀mmí Mimọ́ lóyun, Ẹniti a bí ninu Maria Wundia, Ẹniti o jìya lọwọ́

Digitized by Google

Pontiu Pilatu, Ẹniti a kàn mọ́ agbelebu, Ẹniti o kú, ti a sì sin, O sọkalẹ rè ipò okú; Ni ijọ́ ẹkẹta o tún jinde kuro ninu okú, O rè oke ọrun, O sì joko li ọwọ́ ọtún Olọrun Babba Olodumare; Nibẹ̀ ni yio gbé ti pada wá lati ba ãye on okú wijọ́.

Mo gbà Ẹmmí Mímọ́ gbọ́; Ati Ijọ́ mímọ́ ti awọn enia Olọrun; Ati Idapọ ti awọn Enia mímọ́; Idariji ẹ̀ṣẹ; Ajinde ara ni isà okú, Ati ìye ti kò nipẹkun. Amin.

Alufa. Ki Oluwa ki o pẹlu nyin.

Idahun. Ki o sì pẹlu ẹmmí rẹ.

Alufa. Ẹ jẹ ki a gbadura.
Oluwa, ṣãnu fu wa.

Idahun. Kristi ṣãnu fu wa.

Alufa. Oluwa ṣãnu fu wa.

ADURA OLUWA.

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọ̀wọ́ li orukọ rẹ. Ijọbba rẹ de. Ifẹ́ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ojọ́ wa loni. Dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa, Bi a ti ndari ẹ̀ṣẹ jì awọn ti o ṣẹ̀ wa. Má fà wa sinu idẹwò; Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin. Amin.

Alufa. Oluwa, fi ãnu rẹ hàn fu wa.

Idahun. Ki iwọ ki o sì fu wa ni igbala rẹ.

Alufa. Oluwa, gbà Ọbba là.

Idahun. Ki iwọ ki o sì fi ãnu gbọ́ ti wa, nigbati awa ba npè orukọ rẹ.

Alufa. Fi ododo wọ̀ awọn Alufa rẹ.

Idahun. Ki iwọ ki o sì fu awọn enia ayanfẹ rẹ li ayọ̀.

Alufa. Oluwa, gbà awọn enia rẹ là.

Idahun. Ki iwọ ki o sì bukún u fu ilẹ-ini rẹ.

Digitized by Google

Alufa. Fu wa li alafia ni igba ti wa, Oluwa.

Idahun. Nitori ti kò si ẹlomĩ ti ngbija wa, bikoṣe iwọ nikanṣoṣo, Ọlọrun.

Alufa. Ṣe àiya wa ki o di mimọ́ ninu wa, Ọlọrun.

Idahun. Ki iwọ ki o sì má gbà Ẹmmí Mimọ́ rẹ lọwọ́ wa.

ADURA EKEJI ALẸ.

OLỌRUN, lọdọ ẹniti ifẹ́ mimọ́ gbogbo, ìmọ rere gbogbo, ati iṣẹ́ otitọ gbogbo ti wá; Fi irú alafia ni fu awọn ọmmọ ọdọ rẹ, ti aiye kò le fi fu ni; ki ọkkàn wa ki o le balẹ lati ma pa ofin rẹ mọ́, ati pẹlu bi a ti ndãbobo wa lati ọdọ rẹ wá, ni ifoiya awọn ọtá wa, ki awa ki o le ma rìn ọjọ wa li alafia on idakẹjẹ; nitori itoye Jesu Kristi Olugbala wa. *Amin.*

ADURA ẸKẸTA ALẸ.

ṢE imọlẹ si òkunkun wa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, Oluwa; nitori ãnu rẹ nla dãbobo wa ninu gbogbo ewu alẹ yi; nitori ti ifẹ́ Ọmmọ rẹ nikanṣoṣo, Jesu Kristi Olugbala wa. *Amin.*

ADURA FU ỌBBA.

OLUWA Babba wa ti mbẹ li ọrun, oloruko giga ati alagbara, Ọbba awọn ọbba, Oluwa awọn oluwa, iwọ nikanṣoṣo Oluṣọ awọn ọmmọ-alade, iwọ ti o nti ori itẹ́ rẹ wò gbogbo awọn araiye; Tọkkàn tọkkàn wa gidigidi li awa fi mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o fi oju ore-ọfẹ rẹ wò N— Ọbba. (Bãlẹ) wa. Fi ore-ọfẹ ti Ẹmmí Mimọ́ rẹ fu u, ki àiya rẹ̀ ki o le ma yipada nigba-gbogbo si ifẹ́ ti rẹ, ki o sì le ma rìn li ọna rẹ: Fi ẹ̀bun rẹ ọrun fu u pipọ̀, ki o le ma tọju ọlá ati ogo rẹ; Fu u ni ilera ati ilọrọ̀

Digitized by Google

ki on ki o gbó ki o tọ́ li aiye, ki o sì le ma jọbba awọn enia li ododo rẹ, ati ki o sì le ma pa wọn mọ́ li alafia; Kún u lọwọ́ ki o le lé ati ki o le ṣẹgun awọn ọtá rẹ̀ gbogbo; ati lẹhin aiye yi, ki o le de ibi ayọ̀ on ibukún rẹ ti kò nipẹkun; nitori Jesu Kristi, Oluwa wa. *Amin.*

ADURA FU IDILE ỌBBA, ATI AWỌN OLORI GBOGBO.

OLỌRUN Olodumare, Olorisọn ohun rere gbogbo; Alãbo gbogbo awọn ti o gbẹkẹle ọ; Awa nfi irẹlẹ ohùn bẹbẹ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o bukún u fu gbogbo idile Ọbba (Bãlẹ), awọn ìgbimọ, awọn olori, ati awọn balagun ilẹ yi gbogbo. Mu ohun ipalara gbogbo kuro lọdọ wọn, ki o sì fu wọn ni ilera, agbara, ati alafia li ọjọ aiye wọn. Dãbobo wọn ninu gbogbo ewu ati ipọnju wọn. Fu wọn li ọgbọ́n ọrun, ati ma rò, on ati ma ṣe irú ohun nwọn-ni ti o tọ́ li oju rẹ nigba-gbogbo. Fi ore-ọfẹ rẹ ọrun fu wọn ki nwọn ki o le gbà ọrọ mimọ́ rẹ gbọ́, ki nwọn ki o sì ni ìmọ otitọ ati igbala rẹ, lati ma mọ́ iwọ ẹniti ṣe olugbala araiye, ati lati ma sìn ọ nitõtọ. Olọrun ninu ãnu rẹ nla pa wọn mọ́ lọdọ rẹ li aiye, ati lẹhin aiye yi ki o sì mu wọn wá si ijọbba ọrun rẹ, nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

ADURA FU AWỌN ALUFA ATI ENIA.

OLODUMARE ati aiye-raiye Olọrun, iwọ nikanṣoṣo ti o le ṣe ohun iyanu nla; Rán Ẹmmí ilera ti ore-ọfẹ rẹ silẹ si ori awọn Olori Alufa, ati si awọn Alufa wa, ati si gbogbo Ijọ awọn enia ti a fi si isọ́ wọn; nitõtọ ki nwọn ki o le ma ṣe bi yio ti wù ọ, ma da ìri ibukún

Digitized by Google

rẹ si wọn nigba-gbogbo. Ọlọrun, fi eyi fu wọn, nitori ọllá Alagbawi ati Onilaja wa, Jesu Kristi. *Amin.*

ADURA TI KRISOSTOMU.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o ti fu wa ni ore-ọfẹ nisisiyi lati fi iye ṣe ọkkàn kan wa ìbẹbẹ lọdọ rẹ; iwọ sì ti ṣe ileri pe, nigbati ẹni meji tabi mẹta ba kó ara wọn jọ li Orukọ rẹ, iwọ o fi ìbere wọn fu wọn: Oluwa, mu ifẹ inu ati ìbere awọn ọmmọ ọdọ rẹ ki o ṣẹ nisisiyi, bi yio ti le gbè fu wọn julọ; ma fi ìmọ otitọ rẹ fu wa li aiye yi, ati li aiye ti mbọ̀ ìye aìnipẹkun. *Amin.*

2 KOR. 13. 14.

ORE-ỌFẸ Jesu Kristi Oluwa wa, ati ifẹ Ọlọrun, ati idapọ ti Ẹmmí Mimọ́, ki o ma ba gbogbo wa gbé si i lailai. *Amin.*

LITANI.

OLỌRUN Babba ọrun: ṣãnu fu wa òtoṣi ẹlẹṣẹ.

Ọlọrun Babba ọrun: ṣãnu fu wa òtoṣi ẹlẹṣẹ.

Ọlọrun Ọmmọ, Olurapada araiye: ṣãnu fu wa òtoṣi ẹlẹṣẹ.

Ọlọrun Ọmmọ, Olurapada araiye: ṣãnu fu wa òtoṣi ẹlẹṣẹ.

Ọlọrun Ẹmmí Mimọ́, ti o nti ọdọ Babba ati Ọmmọ wá: ṣãnu fu wa òtoṣi ẹlẹṣẹ.

Ọlọrun Ẹmmí Mimọ́, ti o nti ọdọ Babba ati Ọmmọ wá: ṣãnu fu wa òtoṣi ẹlẹṣẹ.

Digitized by Google

Ẹni Mimọ́, olubukún, ati ologo mẹta, Mẹtalọkan ṣugbọn Ọlọrun kanṣoṣo: ṣãnu fu wa ọ̀tọ̀ṣi ẹlẹṣẹ.

Ẹni Mimọ́, olubukún, ati ologo, mẹta, Mẹtalọkan ṣugbọn Ọlọrun kanṣoṣo: ṣãnu fu wa ọ̀tọ̀ṣi ẹlẹṣẹ.

Má ranti ẹ̀ṣẹ wa, Oluwa, ati ẹ̀ṣẹ awọn babba nla wa; bẹ̃ni ki iwọ ki o má gbẹsan ẹ̀ṣẹ wa: Oluwa rere, da wa si, da awọn enia rẹ si, ti iwọ ti fi ẹ̀jẹ rẹ iyebiye rà pada, ki iwọ ki o má sì binu si wa pẹ titi.

Oluwa rere, da wa si.

Ninu tulasin on alusin gbogbo; ninu ẹ̀ṣẹ, ninu arekereke ati ikọ̀lù ẹ̀ṣu; ninu ibinu rẹ, ati ninu ẹbi àlnipẹkun.

Oluwa rere, gbà wa là.

Ninu gbogbo àlrina àiya; ninu irera, ogo asan, ati agabagebe; ninu ojunla, irira, ati arankan, ati ninu alfẹni gbogbo.

Oluwa rere, gbà wa là.

Lọwọ́ panṣaga, ati lọwọ́ gbogbo okú ẹ̀ṣẹ; ati lọwọ́ gbogbo itanjẹ ti aiye, ti ara, ati ti ẹ̀ṣu.

Oluwa rere, gbà wa là.

Ninu manamana, ati ẹfũfu; ninu ajakalẹ arun, idarun-silẹ, ati ìyan; lọwọ́ ogun ati ipania, ati lọwọ́ ikú ojijì.

Oluwa rere, gbà wa là.

Lọwọ́ ìṣọ̀tẹ-si, idipọ ìkọkọ, ati ikọsilẹ gbogbo; ninu ikọni eke, adamọ on iyapa gbogbo; lọwọ́ lile àiya, ati lọwọ́ gigan Ọ̀rọ on Ofin rẹ.

Oluwa rere, gbà wa là.

Fi ọ̀rọ ijinlẹ ti Imawọ-ara rẹ mimọ́; fi Ibí ati Ikọla rẹ mimọ́; fi Ibaptismu, Awẹ, ati Idanwò rẹ, gbà wa là.

Oluwa rere, gbà wa là.

Fi Iwaya-ìja ati Õgun ẹ̀jẹ rẹ; fi Irora on

Digitized by Google

Ijiya rẹ ; fi Ikú ati Sisin rẹ iyebiye ; fi Ajinde ati Igoke rè ọrun rẹ ti o li ogo ; ati fi wíwa Ẹmmí Mimọ́ gbà wa là.

Oluwa rere, gbà wa là.

Ni igba ipọnju wa gbogbo ; ni igba ọrọ̀ wa gbogbo ; ni wakati ikú, ati li ọjọ idajọ́.

Oluwa rere, gbà wa là.

Awa ẹlẹṣẹ mbẹbẹ lọdọ rẹ lati gbọ́ ti wa, Olọrun Oluwa ; ki o le wù ọ lati ṣọ́ on ati tọ́ gbogbo Ijọ awọn enia mimọ́ rẹ li ọna titọ.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati pa N— Obba mọ́, Ommọ ọdọ rẹ, ki iwọ ki o sì mu u ró ni sisìn rẹ tõtọ li ododo ati ni mimọ́ ìwa.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati ma ko o li àiya so ni igbagbó, ìbẹru, ati ni ifé ti rẹ, ati titi lai ki o ma ni igbẹkẹle lọdọ rẹ, ati lai ki o ma tọju iyìn ati ogo rẹ.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati ṣe alãbo ati olupamọ́ rẹ̀, ma fu u ni iṣẹgun lori awọn ọtá rẹ gbogbo.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati bukun u fu gbogbo idile Obba (Bãlẹ) on ati pa wọn mọ́.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati fi ìmọ ati oyé otitọ ti Ọrọ rẹ ṣe imọlẹ si awọn Olori Alufa, ati si awọn Alufa gbogbo ; ki nwọn ki o le ma fi iwasu ati ìwa wọn gbẹ e kalẹ, ati ki nwọn ki o sì ma fi i hàn bẽ gẹgẹ.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati fi ore-ọfẹ, ọgbọ́n ati oyé fu awọn ọmmọ-alade, awọn ìgbimọ, ati awọn ọlọlá gbogbo.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Digitized by Google

Ki o le wù ọ lati bukún u fu awọn onidajọ́, ati awọn alatunṣe ilu, ki iwọ ki o sì ma ṣọ́, wọn, ma fu wọn li ore-ọfẹ lati ṣiṣẹ otitọ, on ati di ododo mu.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati bukún u fu gbogbo awọn enia rẹ, on ati pa wọn mọ́.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati bù gbogbo awọn ara ilu wa, ati awọn orilẹ ède gbogbo ni iṣọkan, alafia, ati irẹpọ.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati fu wa li àiya lati fẹ on ati bèru rẹ, on ati fi alṣemẹlẹ gbé bi ofin rẹ.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati bù gbogbo awọn enia rẹ ni ibisi ore-ọfẹ lati fi sũru gbọ́ Ọrọ rẹ, on ati fi ọkkàn mimọ́ gbà a, ati lati so eso ti Ẹmmí.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati mu gbogbo awọn ti o ṣìna, ati awọn ti a ti ntàn-jẹ, já òna otitọ.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati tì awọn ti o duro lẹhin; ati lati rẹ on ati ràn awọn alàìle àiya lọwọ́; ati lati gbé awọn ti o ṣubu dide; ati lati tẹ̀ èṣu mọlẹ li atẹlẹsẹ wa.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati ràn gbogbo awọn ti o wà li ewu, li alàìni, ati wahalà lọwọ́, ki iwọ ki o sì tù wọn ninu.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati ṣọ́ gbogbo awọn ti nrìn ni ilẹ ati li oju omi, gbogbo awọn obiri ti nrọbi ọmmọ, gbogbo awọn olokurùn enia, ati awọn ọmmọ wẹ́rẹ; ati lati ṣãnu fu gbogbo awọn arãtubu ati igbekun.

Oluwa rere, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Digitized by Google

Ki o le wù ọ lati dãbobo, ati lati pèse fu, awọn ọmmọ alaìni babba, ati awọn opó, ati gbogbo ẹniti o di alahoro ati òjiya;

Oluwa rere, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati ṣãnu fu gbogbo awọn enia;

Oluwa rere, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati dariji awọn ọtá wa, awọn oninunibini, ati ẹlẹgàn, ati ki iwọ ki o sì pa wọn li àiya da;

Oluwa rere, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati fi onirũru eso ilẹ ore rẹ tọrẹ fu wa, ki iwọ ki o sì pa wọn mọ́ fu ìlo wa, ki awa ki o le ma jẹ ifa wọn li akokò;

Oluwa rere, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ki o le wù ọ lati fu wa ni ironupiwada otitọ; ki iwọ ki o sì dari gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wa, ti igbagbera, ati ti aìmọ; ati lati fi ore-ọfẹ ti Ẹmmí Mimọ́ rẹ wọ̀ wa, lati tún ìwa wa ṣe gẹ̀gẹ̀ bi Ọrọ mimọ́ rẹ;

Oluwa rere, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ọmmọ Ọlọrun: awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ọmmọ Ọlọrun: awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ gbọ́ ti wa.

Ọdọ agutan Ọlọrun: ti o kó ẹ̀ṣẹ̀ aiye lọ;

Fi alafia rẹ fu wa.

Ọdọ agutan Ọlọrun: ti o kó ẹ̀ṣẹ̀ aiye lọ;

Ṣãnu fu wa.

Kristi, gbọ́ ti wa.

Kristi, gbọ́ ti wa.

Oluwa, ṣãnu fu wa.

Oluwa, ṣãnu fu wa.

Kristi, ṣãnu fu wa.

Kristi, ṣãnu fu wa.

Oluwa, ṣãnu fu wa.

Oluwa, ṣãnu fu wa.

Digitized by Google

LITANI.

ADURA OLUWA.

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọwọ li orukọ rẹ. Ijọbba rẹ de. Ifẹ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ọjọ wa loni. Dari ẹṣẹ wa jì wa, Bi a ti ndari ẹṣẹ jì awọn ti o ṣẹ wa. Má fà wa sinu idẹwò; Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin. Amin.

Alufa. Oluwa, má hùwa si wa bi ẹṣẹ wa.

Idahun. Ki iwọ ki o má sì san a fu wa bi ẹṣẹ wa.

Jẹ ki a gbadura.

Alufa. ỌLỌRUN, Babba alãnu, ti kì igàn ironu ti irora àiya, ati ifẹ irú awọn ti inu wọn bajẹ; Fi ãnu ràn adura wa lọwọ́, ti awa ngbà niwaju rẹ ninu gbogbo iṣẹ ati ipọnju wa, nigba-kũgba ti nwọn ba nwọ̀ wa li ọrùn; ki iwọ ki o sì fi ore-ọfẹ gbọ́ ti wa, ki ibi wọn-ni, ti arekereke on ọgbọ́n-kọgbọn èṣu ati ti enia nṣe si wa, ki o di asan; ati ni ìpese ti ore rẹ ki a tú wọn ká; li alfi inunibini pa-ni lara, ki awa awọn ọmmọ ọdọ rẹ ki o ma dupẹ lọwọ́ rẹ titi ni Ijọ awọn enia mimọ́ rẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa.

Idahun. Oluwa, dide, ki o ràn wa lọwọ́, ki o sì gbà wa là nitori Orukọ rẹ.

Alufa. Ọlọrun, awa ti fi etí wa gbọ́, awọn babba wa sì ti sọ fu wa, ni iṣẹ nla ti iwọ ṣe li ọjọ wọn, ati ni igbani niwaju wọn.

Idahun. Oluwa, dide, ki o ràn wa lọwọ́, ki o sì gbà wa là nitori ọllá rẹ.

Alufa. Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí Mimọ́;

Idahun. Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẽni yio sì ma ri nigba-gbogbo: aiye alnipẹkun. Amin.

Digitized by Google

Alufa. Lọdọ awọn ọtá wa, Kristi dãbobo wa.

Idahun. Fi ọju ore-ọfẹ wò ipọnju wa.

Alufa. Fi ãnu wò irora àiya wa.

Idahun. Fi iyọnu dari ẹ̀ṣẹ̀ jì awọn enia rẹ.

Alufa. Lojurere fi ãnu gbọ́ adura ti wa.

Idahun. Ọmmọ Dafidi, ṣãnu fu wa.

Alufa. Nisisiyi ati lai, Kristi fiyesi lati gbọ́ ti wa.

Idahun. Lojurere Kristi gbọ́ ti wa; lojurere Kristi Oluwa gbọ́ ti wa.

Alufa. Oluwa, jẹ ki ãnu rẹ ki o ma hàn fu wa.

Idahun. Bi awa ti ngbẹ̀kẹ̀ wa le ọ.

Jẹ ki a gbadura.

BABBA, awa nfi irẹlẹ ohùn tọrọ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o fi oju ãnu wò allera wa; ati nitori ogo Orukọ rẹ, ṣẹ̀ri gbogbo ibi wọn-ni kuro lọdọ wa, ti awa ti njigbese si ọrùn nitõtọ; ki iwọ ki o sì fu ni, ki awa ki o ma gbẹ̀kẹ̀le, ati ki a ma fi ọkkàn so ãnu rẹ ni gbogbo iṣẹ́ wa, ati titi lai ki a ma sìn ọ ni mimọ́ ìwa ati lallẽri, fu ọllá on ogo rẹ; nitori Onilaja ati Alagbawi wa nikanṣoṣo, Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

ADURA TI KRISOSTOMU.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o ti fu wa ni ore-ọfẹ nisisiyi lati fi iye ṣe ọkkàn kan wa ìbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ; iwọ sì ti ṣe ileri pe, nigbati ẹni meji tabi mẹta ba kó ara wọn jọ li Orukọ rẹ, iwọ o fi ìbere wọn fu wọn: Oluwa, mu ifẹ́ inu ati ìbere awọn ọmmọ ọdọ rẹ ki o ṣẹ nisisiyi, bi yio ti le gbè fu wọn julọ; ma fi ìmọ otitọ rẹ fu wa li aiye yi, ati li aiye ti mbọ̀ ìye ainipẹ̀kun. *Amin.*

Digitized by Google

LITANI.

2 Kor. 13. 14.

ORE-ỌFẸ Jesu Kristi Oluwa wa, ati ifẹ Ọlọrun, ati idapọ ti Ẹmmí Mimọ́, ki o ma ba gbogbo wa gbé si i lailai. *Amin.*

ADURA ATI ỌPẸ́.

FU ONIRŨRU IGBA.

ADURA.

Fu Òjo.

OLỌRUN, Babba ọrun, nipa ti Jesu Kristi Ọmmọ rẹ iwọ ti o ṣe ileri ohun gbogbo ti a kò le ṣe alalni fu bibọ́ ara, fu gbogbo awọn ti nwá ijọbba rẹ, ati ododo rẹ ri. Awa mbẹbẹ lọdọ rẹ ninu alni ti wa yi, rán irú òwara òjo bẽ si wa, ki awa ki o le ma ri eso ilẹ aiye mu fu itunu wa, ati fu ọllá rẹ; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Fu oju Ọjọ Didara.

OLUWA Ọlọrun Olodumare, nitori èṣẹ enia iwọ ti o rì gbogbo araiye nigba kan, bikoṣe enia mẹjọ pére, ati nigba ẹhin nipa ãnu rẹ nla ti o ṣe ileri pe, lai iwọ kì yio sì run u bẽ mọ́; Awa nfi irẹlẹ ohùn bẹbẹ lọdọ rẹ, pe nitori èṣẹ wa, bi awa tilẹ yẹ lati jìya iyọnu ti òjo ati ti omi lọwọ́ rẹ, ṣugbọn nipa ironupiwada wa otitọ, iwọ yio rán irú ọjọ didara bẽ, ti awa yio fi le ma ri eso ilẹ aiye mu li akokò; ki a sì ma kẹkọ, ati nipa ibawi rẹ, lati ma ṣe atun-hù rere ìwa, ati nitori lakari rẹ lati ma fi iyìn ati ogo fu ọ; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Ni igba Ọdá ati Ìyan.

ỌLỌRUN, Babba ọrun, ẹbun ẹniti ṣe, ti òjo fi nrò, ti ilẹ aiye fi nseso òpọlọpọ, ti ẹranko mbisi i, ti ẹja sì nrẹ̀ si i; Kiyesi, ipọnju ti awọn enia rẹ yi, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ; ki iwọ ki o sì fifuni, ki ọwọ́n ati ọdá yi, ti awa njìya nisisiyi bi o ti yẹ julọ nitori èṣẹ wa, nipa ore rẹ ki o fi ãnu yi i pada si òpọlọpọ; nitori ti ifẹ Jesu Kristi Oluwa wa, ẹni pẹlu rẹ ati Ẹmmí Mimọ́ ti gbogbo ọlá ati ogo mbẹ fu, nisisiyi ati lailai. *Amin.*

Tabi eyi.

ỌLỌRUN, Babba alãnu, ni igba woli Elisa, iwọ ti o sọ ọwọ́n ati ọdá di òpọlọpọ lojijì ni Samaria; Ṣãnu fu wa, ki awa, ti a nfi irú ipọnju bẹ̃ ṣẹ nisẹ nisisiyi nitori èṣẹ wa, pẹlu ki a le ri itura akokò gbà bẹ̃ gẹgẹ: Mu eso ilẹ so asọkún nipa ibukún rẹ orun; ki o sì fifuni ki awa, ti ngbà òpọlọpọ ọrẹ rẹ yi, ki a le ma lò eyi na si ogo rẹ, si irọra awọn ti ṣe alaìni, ati si itunu awa tikara wa; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Ni igba Ogun ati Irukerudò.

ỌLỌRUN Olodumare, Ọbba awọn ọbba gbogbo ati Bãlẹ ohun gbogbo, agbara ẹniti ẹda kan kò le dojukọ, ati ẹniti lati ṣẹ̀ ẹlẹṣẹ nisẹ nitõtọ ṣe, ati lati ṣãnu fu awọn ti o ronupiwada nitõtọ; Gbà wa là ki o sì da wa silẹ kuro lọwọ́ awọn ọtá wa, awa nfi irẹlẹ ohùn bẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ; ke igberaga wọn kun, fà arankan wọn sẹhin, ki o sì dà ìrokuro wọn rú; ki awa, ti a nfi àbo rẹ dì ni ihamọra ogun, ki o le di ẹni ipamọ́ siwaju kuro ninu ewu gbogbo, lati ma yìn ọ logo, iwọ nikanṣoṣo ti

Digitized by Google

ṣe olufuni ni iṣẹgun gbogbo; nipaṣẹ itoye ti Ọmmọ rẹ nikanṣoṣo, Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Ni igba Ajaka iyọnu kan tabi Arun.

OLỌRUN Olodumare, ninu ibinu rẹ iwọ ti o rán arun wá sara awọn enia ara rẹ li aganjù, nitori algbọran lṣọtẹ wọn si Mose ati Aaron; ati pẹlu, ni igba Dafidi ọbba, ti iwọ sì fi iyọnu Ajakalẹ arun pa ẹgba marun-di-logoji enia, ṣugbọn ti iwọ nranti ãnu rẹ o sì da awọn iyokùn si; Ṣe iyọnu si awa òtoṣi ẹlẹṣẹ, ti a nfi arun nla ati ikú bẹwò nisisiyi; pe bi iwọ ti gbà èmutù nigba na, ti o sì paṣẹ fu Angeli apanirun ni lati dawọ ibaniwi duro, bẽni ki o sì wù ọ nisisiyi lati fàwọ iyọnu ati arun buburu yi sẹhin kuro lara wa; nipaṣẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Adura fu awọn ti a o gbà si Oyè Mimọ́ Alufa.

OLỌRUN Olodumare, Babba wa ti mbẹ lọrun, iwọ ti o fi ẹjẹ iyebiye ti Ọmmọ rẹ ọwọn rà gbogbo Ijọ awọn enia fu ara rẹ; Li oju ãnu wò eyi na, ati ni igba isisiyi ṣe afọnahan, ki o sì ṣe akoso inu awọn iranṣẹ rẹ tobẽ, ki awọn Olori Alufa, ati ti awọn Olutọju ti agbo awọn enia rẹ, ki o máṣe tète súre gbé ọwọ́ le ẹnikẹni, ṣugbọn bikoṣe nitõtọ ati ti iwoye ki nwọn ki o ma ṣà awọn ẹniti o yẹ, lati ma sinsìn ninu Iṣẹ́ Alufa ni mimọ́ niti Ijọ awọn enia rẹ. Ati awọn ti a o fi joye si oyè-koye mimọ́ kan, ni ki iwọ ki o fi ore-ọfẹ ati ibukún rẹ ọrun fu; ati nipa lwa ati ẹkọ́ wọn, ki nwọn ki o le ma gbé ogo rẹ kalẹ, ki nwọn ki o sì le ma sún igbala ti gbogbo awọn enia siwaju; nipaṣẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Tabi Eyi.

OLỌRUN Olodumare, olufuni li ẹbun rere gbogbo, ninu olori-ori ìpese rẹ ọrun, iwọ ẹniti o yàn onirũru Ilasilẹ ninu Ijọ awọn enia rẹ; Awa nfi irẹlẹ ohùn bẹbẹ lọdọ rẹ, fi ore-ọfẹ rẹ fu gbogbo awọn ti a o pè si oyè-koye ati ipinfuni ninu rẹ na; ki o sì fi otitọ ẹkọ́ rẹ kún wọn, ati ki o sì fi ìwa alṣẹ-alro wò wọn tobẹ ki nwọn ki o le ma sìn niwaju rẹ nitõtọ, fu ogo Orukọ rẹ nla, ati fu anfani Ijọ awọn enia mimọ́ rẹ; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Adura ti a le ma gbà lẹhin ọkan ninu eyi ti o ti ṣaju.

OLỌRUN, ìwa ati ini ẹniti ṣe lai ki a ma ṣãnu on ati ṣe idariji, gbà ẹbẹ irẹlẹ wa wọnyi; bi awa tilẹ ti fi ẹ̀wọn ẹ̀ṣẹ wa dì, ti a sì fi dè wa ni ìde, ṣugbọn jẹ ki iyọnu ãnu rẹ nla ki o tú wa silẹ; nitori ọ̀llá Jesu Kristi Onilaja ati Alagbawi wa. *Amin.*

Adura fu Ajọ awọn Igbimọ.

OLỌRUN olore-ọfẹ julọ, awa nfi irẹlẹ ohùn bẹbẹ lọdọ rẹ, fu gbogbo Ilẹ Ọbba yi, ati pẹlu-pẹlu fu Ajọ awọn Igbimọ ti o pejọ labbẹ oyè Ọbba wa: Ki o le wù ọ lati ṣe amọ̀na wọn, ki iwọ ki o sì mu gbogbo ìmọ wọn, ki o jasi aṣẹ rere fu igbeleke ogo rẹ, fu ire Ijọ awọn enia rẹ, fu àbo, ọ̀llá, ati alafia Ọbba wa, ati ti Ijọbba rẹ; ki a le ma ṣe làna ohun gbogbo, ati ki a ma ṣe pin-nu tobẹ nipa iyanju wọn, lori ipilẹ, didara ati didaniloju jù bẹ lọ, ki alafia ati irọra, otitọ ati ododo, ìsin Olọrun ati ifọkkànsin, ki o le fi ẹsẹ mulẹ ninu wa, ati ninu iran-iran wa gbogbo. Nwọnyi ati gbogbo

Digitized by Google

ohun alni iyokùn, fu wọn, fu wa, ati fu gbogbo Ijọ awọn enia Olọrun, li awa mbẹbẹ li Orukọ ati ni Ilaja Jesu Kristi ti Olubukún julọ Oluwa ati Olugbala wa. *Amin.*

Adura fu gbogbo Oniwa-iwa Enia.

OLỌRUN, Ẹlẹda ati Olupamọ gbogbo araiye, awa nfi irẹlẹ ohùn bẹbẹ lọdọ rẹ, fu gbogbo onirũru ati oniwa-iwa enia; ki o le wù ọ lati fi ọna rẹ hàn fu wọn, ati lati fi igbala ilera rẹ hàn fu gbogbo orilẹ ède. Pẹlu-pẹlu awa ngbadura fu ìwa rere ti Ijọ mimọ ti awọn enia Olọrun; ki a le ma ṣe amọna rẹ, ati ki a le ma tọ ọ lati ọdọ Ẹmmí rere rẹ wá, ki a le ma mu gbogbo awọn ẹniti o jẹwọ, ti nwọn sì npè ara wọn ni Kristian, tọ ọna otitọ, lati ma fi idapọ ọkkàn mu igbagbọ ni idipọ alafia, ati li ododo ìwa. Lakotan, awa fi gbogbo enia le ore rẹ bi ti babba lọwọ, nibikibi ti nwọn nṣiṣe, tabi ti nwọn nwahala, li ọkkàn, li ara, tabi ni ìwa; (*pẹlu-pẹlu fu awọn ti a mbẹbẹ adura wa fu*) ki o le wù ọ lati tù wọn ninu ati lara, gẹgẹ bi onirũru alni olukuluku, ma fu wọn ni sũru ninu ipọnju wọn, ati amuwa rere ninu iṣẹ wọn gbogbo. Eyiyi li awa mbẹbẹ nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

ỌPẸ.

ỌPẸ FU OHUN GBOGBO.

OLỌRUN Olodumare, Babba ãnu gbogbo, awa ọmmọ ọdọ rẹ alallere nfi irẹlẹ ohùn ati tọkkàn-tọkkàn dupẹ lọdọ rẹ, nitori gbogbo ore ati iṣeun ifẹ rẹ fu wa, ati fu gbogbo awọn enia; (*pẹlu-pẹlu fu awọn ti nfẹ nisisiyi lati fi*

Digitized by Google

iyìn on ati dupẹ fu ọ, nitori ãnu rẹ ti iwọ ṣe u wọn ni lọlọyi.) Awa nfi iyìn fu ọ, nitori dida wa, nitori ipamọ́ wa, ati nitori gbogbo ibukún aiye yi; ṣugbọn jù gbogbo rẹ̀ lọ, nitori ifẹ́ rẹ alniye niti idande araiye, nipa Jesu Kristi Oluwa wa; nitori amuba ore-ọfẹ, ati nitori ireti ogo. Awa sì mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o fu wa, lati ma more ãnu rẹ gbogbo ti o yẹ, ki ọkkàn wa ki o le ma fi alṣẹtan dupẹ, ki awa ki o sì le ma fi iyìn rẹ hàn, kì iṣe ni kìki ète wa, bikoṣe ni ìwa wa; lati ma fi ara wa fu sinsìn rẹ, ati lati ma rìn niwaju rẹ, ni mimọ́ ìwa ati li ododo li ọjọ wa gbogbo; nitori Jesu Kristi Oluwa wa, ẹniti o pẹlu iwọ ati Ẹmmí Mimọ́, ti a nfi ọlá ati ogo gbogbo fu, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Fu Òjo.

OLỌRUN Babba wa ti mbẹ li ọrun, nipa ìpese ore-ọfẹ rẹ, iwọ ti o mu akọrọ̀ ati àrọ-kuro òjo rọ̀ si ori ilẹ, ki o le ma so eso jade fu ìlo enia; Awa nfi ọpẹ́ irẹlẹ ohùn fu ọ, nitori ti o wù ọ ninu ipọnju wa nla, lati rán òjo ayọ̀ si ilẹ-ini rẹ fu wa nigba ikẹhin, ati lati tù u loju nigbati o gbẹ, fu itunu nla awa iranṣẹ rẹ alaìyẹ, ati fu ogo Orukọ rẹ mimọ́; nipasẹ ãnu rẹ niti Jesu Kristi Oluwa. *Amin.*

Fu Oju Ọjọ didara.

OLỌRUN Oluwa, iwọ ti o fi iyọnu rẹ lọlọyi ti almọniwọn òjo ati omi, rẹ̀ wa silẹ bi o ti yẹ, ati ninu ãnu rẹ iwọ sì fi ara wa balẹ, o sì tù ọkkàn wa ninu, nipa ọjọ didara ati ayipada akokò yi ti o ni ibukún. Awa nfi iyìn fu, awa sì nyìn Orukọ mimọ́ rẹ logo nitori ãnu rẹ yi, awa o sì ma sọ̀rọ iṣeun ifẹ́ rẹ nigba-gbogbo ati iran-diran; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

ỌPẸ́.

Fu Ọ̀pọ.

BABBA alãnu julọ, nipa ore-ọfẹ rẹ iwọ ti o gbọ́ adura ifọkkàn gbà ti Ijọ awọn enia rẹ, ti o sì sọ ọdá ati ọwọ́n wa di ọ̀pọ̀ pupọ̀; Awa nfi fi irẹlẹ ohùn ọpẹ́ fu ọ nitori akanṣe ọ̀pọ̀ rẹ yi; awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ ki iwọ ki o mu iṣeun ifẹ́ rẹ duro pẹ fu wa, ki ilẹ wa ki o le ma so eso asọnkún rẹ̀, fu ogo rẹ ati itunu wa; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Fu Alafia ati Igbala kuro lọwọ́ awọn Ọtá wa.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti ṣe ile-odi agbara àbo fu awọn iranṣẹ rẹ si oju awọn ọtá wọn; Awa nfi iyìn ati ọpẹ́ fu ọ nitori igbala wa yi kuro ninu ewu nla nwọnyi, ti o hàn gbangba, ti a fi ka wa mọ́: Awa jẹwọ rẹ̀ si ore rẹ ti a kò fi wa le wọn lọwọ́ bi ijẹ ikogun fú wọn; awa mbẹ̀ ọ sibẹ̀ ki iwọ ki o ma mu irú ãnu bẹ̃ duro si wa pẹ titi, ki gbogbo araiye ki o le ma mọ pe, iwọ li Olugbala ati Ọgbagba wa alagbara; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Fu imupada Alafia si gbogbo Ilu ni Ilẹ wa.

AIYE-RAIYE Ọlọrun, Babba wa ti mbẹ li ọrun, iwọ nikanṣoṣo ti o mu enia ṣe Oninukan ninu ile, ti o sì mu irọkẹ̀kẹ oni ìwa-ipa ati ti awọn enia agídi rọsilẹ; Awa nfi ibukún fu Orukọ rẹ mimọ́, nitori ti o wù ọ lati tù irukerudò ọ̀tẹ yi, ti o ru soke ninu wa ni lọlọyi; gidigidi li awa nfi irẹlẹ ohùn bẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o fi ore-ọfẹ fu gbogbo wa, lati isisiyi lọ ki a ma fi igboran rìn ninu ofin rẹ mimọ́; ati bi awa sì ti nfi alafia on idakẹjẹ rìn ọjọ aiye wa ni ìwa-bi-Ọlọrun ati ìwa titọ, ki awa ki o ma ru ẹbọ iyìn ati ọpẹ́ wa fu ọ nigbagbogbo nitori ãnu rẹ nwọnyi si wa; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

ỌPẸ́.

Fu Igbala kuro ninu Iyọnu, tabi Arun omiran.

OLỌRUN Oluwa, iwọ ti o fi ibẹ̀wò rẹ̀ lọlọ̀yi ti o wuwo ti o sì ni lìbẹ̀ru, pa wa lara nitori èṣẹ̀ wa, ti o sì run wa nitori irekọja wa; ati nisisiyi larin idajọ́ iwọ sì nranti ãnu, iwọ sì rà okkàn wa pada kuro lọwọ́ ikú; Awa fi awa tikara wa, ọkkàn wa, ati ara wa le ore-ọfẹ rẹ̀ bi ti babba lọwọ́, ti iwọ gbàla, lati ṣe ẹbọ ãye si ọ, nigba-gbogbo li awa nyìn ti awa sì ngbé ãnu rẹ̀ ga li arin Ijọ awọn enia rẹ̀; nipasẹ̀ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Tabi Eyi.

BABBA alãnu julọ, awa nfi irẹ̀lẹ̀ ohùn jẹ̀wọ́ niwaju rẹ̀, pe gbogbo ibawi ti a fi kìlọ ninu ofin rẹ̀ ni iba ṣubu lù wa bi o ti yẹ̀, nitori ọ̀pọ̀lọpọ̀ irekọja ati lile àiya wa: Ṣugbọn bi o ti wù ọ ninu iyọnu ãnu rẹ̀ lati ṣiju-wò allera wa ati irẹ̀lẹ̀ wa alalye, lati ṣẹ̀wọ́ arankan arun ni kùn, eyi ti a fi pọ́n wa loju bajẹ̀ ni lọlọ̀yi, ati lati mu ohùn ayọ̀ ati ilera pada sinu ile wa; Awa nru ẹbọ iyìn ati ọpẹ́ si Ọlá-nla rẹ̀ Ọrun, awa nyìn, awa sì ngbé Orukọ rẹ̀ ti o logo ga, nitori irú ipamọ́ ati ìpese rẹ̀ yi sori wa; nipasẹ̀ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

ADÙRA

FU AWỌN ỌJỌ ỌLỌRUN ATI ỌJỌ OMIRAN LI ỌDÚN KAN.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKINI NI ADFENTI.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, fifu wa li ore-ọfẹ̀, ki a le bọra iṣẹ́ òkunkun silẹ̀, ki a sì di ihamọra imọlẹ̀, nisisiyi ni igba aiye ikú yi,

Digitized by Google

ninu eyi ti Jesu Kristi Ọmmọ rẹ wá fi irẹlẹ nla bẹ wa wò; nitori pe li opin ọjọ, nigbati on yio sì pada ṇinu Ọlá-nla rẹ ti o logo, lati ba ãye on okú wijọ, ki awa ki o le jinde si ìye alailkú, nitori rẹ ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu iwọ ati Ẹmmí Mimọ, nisisiyi ati lailai. *Amin.*

Episteli. Rom. 13. 8.

EMÁ jẹ ẹnikẹni ni gbese ohun kan, bikoṣepe ki a fẹ ọmmọnikeji ẹni: nitori ẹniti o ba fẹ ọmmọnikeji rẹ, o ko ofin ja. Nitori eyiyi, Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga, Iwọ kò gbọdọ pania, Iwọ kò gbọdọ jale, Iwọ kò gbọdọ jẽri eke, Iwọ kò gbọdọ ṣojukòkoro; bi ofin omiran ba sì wà, li aìfa a gùn lọ titi o wà ninu òrọ yi pe, Iwọ fẹ ọmmọnikeji rẹ bi ara rẹ. Ifẹ kì iṣe ohun buburu si ọmmọnikeji rẹ: nitorina ifẹ li akoja ofin. Ati eyiyi, ti a nmọ akokò pe, o to wakati ati jí loju orun: nitori isisiyi ni igbala wa sumọ etile jù igbati awa ti gbagbọ́ lọ. Orụ bu-kọja tan, ọsán kùn si dẹdẹ: nitorina ẹ jẹ ki awa ki o bọ ara iṣẹ òkunkun silẹ, ki awa ki o sì di ihamọra iṣẹ imọlẹ. Jẹ ki awa ki o ma rìn nitõtọ, bi ọsán; kì iṣe ni irede-oru ati ni imọti para, kì iṣe li asùn ma dide ni yèwu ati aiye jijẹ, kì iṣe ni ìja ati ilara. Ṣugbọn ẹ mu Jesu Kristi Oluwa wọ, ki ẹnyin ki o má sì pèse fu ara, lati ṣe ifẹkufẹ rẹ.

Ihin-rere. Mat. 21. 1.

NIGBATI nwọn sumọ eti Jerusalemu, ti nwọn de Betfage li òke Olifi, nigbana ni Jesu rán awọn ọmmọ ẹhin rẹ meji lọ, o wi fu wọn pe, Ẹ lọ si iletò ti o kọju si nyin, nisisiyi ẹnyin o ri kẹtẹkẹtẹ kan ti a so, ati ọmmọ rẹ pẹlu: ẹ tú wọn, ki ẹnyin ki o sì fà wọn fu mi wá. Bi ẹnikẹni ba sì wi nkan fu

Digitized by Google

nyin, ẹnyin o wi pe, Oluwa ni ifi wọn ṣe; nisisiyi ni yio sì rán wọn wá. Gbogbo eyi li a ṣe, ki eyi ti a ti sọ lati ẹnu woli wá ki o le ṣẹ, pe, Ẹ sọ fu ọmmọbiri Sion pe, Kiyesi i, Ọbba rẹ mbọ̀ wá sọdọ rẹ, o tẹnu, o njoko lori kẹtẹkẹtẹ, ati lori ọmmọ kẹtẹkẹtẹ. Awọn ọmmọ ẹhin na sì lọ, nwọn ṣe bi Jesu ti wi fu wọn; nwọn sì fà kẹtẹkẹtẹ na wá, ati ọmmọ rẹ̀, nwọn sì tẹ́ aṣọ wọn si ẹhin wọn, nwọn si gbé Jesu kà a. Ọpọ ijọ awọn enia tẹ́ aṣọ wọn si ọna; ẹlomiran ṣẹ́ ẹká igi wẹ́wẹ́, nwọn sì fọn wọn si ọna. Ijọ awọn enia ti nlọ niwaju, ati eyi ti ntọ̀ wọn lẹhin, nkigbe wipe, Hosana fu Ọmmọkọnri Dafidi: Olubukún li ẹniti o mbọ̀ wá li orukọ Oluwa; Hosana loke ọrun. Nigbati o de Jerusalemu, gbogbo ilu mì-titi, wipe, Tani yi? Ijọ awọn enia sì wipe, Eyi ni Jesu woli Nasareti ti Galili. Jesu si wọ̀ inu ile Ọlọrun, (tempeli) o lé gbogbo awọn ẹniti ntà, ati ẹniti nrà ni ile Ọlọrun jade, o sì yi tabeli ti awọn onipaṣiparọ owo danù, ati ibujoko awọn ti ntà àdaba, o sì wi fu wọn pe, A kọwe rẹ̀ pe, Ile adura li a o ma pè ile mi; ṣugbọn ẹnyin ti sọ ọ di ihò olè.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKEJI NI ADFENTI.

Adura.

OLUWA Olubukún, iwọ ti ó ti ṣe ati kọ gbogbo Iwe mimọ́ rẹ fu kíkọ wa; Fifuni ki awa le ma gbọ́, ki a ma kà, ki a ma sami si, ki a ma kọ́, ati ki a sì le ma ṣà wọn rò ninu wa tobẹ̃, ki awa ki o le ma fi sũru ati itunu Ọrọ mimọ́ rẹ fà ireti mọra ti o ni ibukún, ki a sì di i mu ṣinṣin, ti iwọ ti fifu wa lara Olugbala wa Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. Rom. 15. 4.

OHUNKOHUN ti a ti kọ tẹlẹ, a ti kọ ọ fu kíkọ wa, nipa sũru ati itunu ti Iwe mimọ́ Ọlọrun ki awa ki o le ni ireti. Njẹ ki Ọlọrun sũru ati itunu ki o fifu nyin lati ma ṣe inu kan si ara nyin bi ìlana Kristi Jesu: ki ẹnyin ki o le fi ọkkàn ati ẹnu kan yìn Ọlọrun logo, on na Babba Jesu Kristi Oluwa wa. Nitorina ẹ gbá ara nyin mọra, gẹgẹ bi Kristi ti gbá wa mọra fu ogo Ọlọrun. Mo sì wipe, Jesu Kristi li o ṣe iranṣẹ ti ikọla nitori otitọ Ọlọrun, lati mu awọn ileri na duro ti a ti ṣe fu awọn babba: Ati ki awọn Keferi ki o le yìn Ọlọrun logo nitori ãnu rẹ; gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Nitori eyiyi emi o jẹwọ fu iwọ ninu awọn Keferi, emi o sì kọnrin si orukọ rẹ. O sì tún wipe, Ẹnyin Keferi, ẹ ma yọ pẹlu awọn enia rẹ. Ati pẹlu, Ẹnyin Keferi gbogbo, ẹ yìn Oluwa; ẹ sì kokikí rẹ ẹnyin enia gbogbo. Isaia si tún wipe, Gbòngbo ti Jese kan mbọ́ wá, ati ẹniti yio dide jọba lori awọn Keferi; on li awọn Keferi yio gbẹkẹle. Njẹ ki Ọlọrun ireti ki o fi gbogbo ayọ́ on alafia kún u fu nyin ni igbagbọ́, ki ẹnyin ki o le pọ̀ ni ireti nipa agbara ti Ẹmmí Mimọ́.

Ihin-rere. Luku 21. 25.

ÀMI yio wà li õrùn, ati li oṣupa, ati ni irawọ; ati li aiye lãlã ti orilẹ ède, ti on ti idamu; okun ati riru omi yio ma hó; àiya awọn enia yio ma já fu ibẹru, ati fu iwoye nkan wọn-ni ti mbọ́ wá aiye: nitori gbogbo agbara ọrun li a o mì-titi. Nigbana ni nwọn o sì ri Ọmmọ Ọkọnri ti yio ma ti oju ọrun bọ́ ti on ti agbara ati ogo nla. Nigbati nkan wọnyi sì bẹrẹ si iṣẹ, njẹ ki ẹnyin ki o ma wò

Digitized by Google

oke, ki ẹnyin ki o sì gbé ori nyin soke; nitori ti idande nyin kùn si dẹ̀dẹ̀. O sì pa owe kan fu wọn pe; Kiyesi igi ọpọtọ, ati si igi gbogbo; nigbati nwọn ba nrúwe, ẹnyin ri, ẹnyin sì mọ̀ fu ara nyin pe, igba ẽrun kùn fẹ̀fẹ̀. Gẹ̀gẹ̀ bẽ na li ẹnyin, nigbati ẹnyin ba ri nkan wọnyi ti nṣẹ̀, ki ẹnyin ki o mọ̀ pe, Ijọba Ọlọrun kùn si dẹ̀dẹ̀. Lõtọ ni mo wi fu nyin, Iran yi kì yio rekọja, titi a o fi mu gbogbo nkan wọnyi ṣẹ̀. Ọrun on aiye yio rekọja: ṣugbọn ọ̀rọ̀ mi kì yio rekọja.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸTA NI ADFENTI.

Adura.

JESU KRISTI Oluwa, li àtetekọwa rẹ̀ iwọ ti o rán onisẹ̀ rẹ̀ lati tún ọna rẹ̀ ṣe niwaju rẹ̀; Fifuni ki awọn alufa ati iransẹ̀ ọ̀rọ̀ ijinlẹ̀ rẹ̀, ki nwọn ki o sì ma tún ọna rẹ̀ ṣe bẽ gẹ̀gẹ̀, lati yi ọkkàn ti awọn alaìgbọran pada si ọgbọ́n olõtọ, ni igba atunwa rẹ̀ lẽkeji lati wa ṣe idajọ́ araiye, ki a le bá wa li ẹni itẹ̀wọgbà li oju rẹ̀, ẹniti o wà ti o sì njọba pẹlu Babba ati Ẹmmí Mimọ́, lai Ọlọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Epistéli. 1 Kor. 4. 1.

JẸ ki enia ki o ma kà wa ṣe bẽ gẹ̀gẹ̀ bi iransẹ̀ Kristi, ati iriju fu awọn ohun ijinlẹ̀ Ọlọrun. Pẹlupẹlu a mbère lọwọ́ iriju pe ki oluwarẹ̀ na ki o jẹ̀ olododo. Ṣugbọn bi o ṣe ti emi ni ohun kikini sá ni fu mi, ti ẹnikẹni yio fi ma wadi mi lọdọ nyin, tabi lati ma ṣe idajọ mi nipa idajọ enia: ani, emi kò ṣe idajọ emi tikarami. Nitoriti emi kò mọ̀ ohunkohun fu ara mi; ṣugbọn nipa eyi na a kò da mi lare:

Digitized by Google

ṣugbọn ẹniti nda mi lare li Oluwa. Nitorina ẹ máṣe idajọ ohunkohun ṣaju akokò na, titi di igbati Oluwa ba de, ẹniti yio mu ohun òkunkun ti o farasin wá si imọlẹ, ti yio sì fi ìmọ ọkkàn hàn pẹlu: nigbana li olukuluku yio sì ni iyìn lọdọ Ọlọrun.

Ihin-rere. Mat. 11. 2.

NIGBATI Johanu gbọ́ iṣẹ Kristi ninu tubu, o rán awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ meji, o sì wipe, Iwọ li ẹniti mbò, tabi ki a ma reti ẹlomiran? Jesu sì dahùn o wi fu wọn pe, Ẹ pada lo, ẹ sì fi ohun wọnyi ti ẹnyin gbọ́, ati eyi ti ẹnyin ri hàn Johanu. Awọn afọju nriran, awọn amọkun nrìn ṣaṣa, a nwẹ̀ awọn adẹtẹ̀ mọ́, awọn aditi ngbọran, a njí awọn okú dide, ati fu awọn òtoṣi li a nwasu ihin rere. Alabukún-fu sì li ẹnikẹni, ti kì yio kọsẹ lara mi. Nigbati nwọn sì lọ, Jesu bẹ̀rẹ si bi awọn enia niti Johanu pe, Kili ẹnyin jade lọ lati wò ni ijù? ifefe nmì fu afẹfẹ? Ani kili ẹnyin jade lọ iwò? ọkọnri ti a wọ̀ li aṣọ fẹlẹfẹlẹ? wò o, awọn ẹniti nwọ̀ aṣọ fẹlẹfẹlẹ mbẹ li afin ọbba. Ani kili ẹnyin jade lọ iwò? woli? lõtọ ni mo wi fu nyin, o sì jù woli lọ. Nitori eyiyi li ẹniti a ti kọwe nitori rẹ̀ pe, Wò o, mo rán oniṣẹ mi siwaju rẹ, ẹniti yio tún ọna rẹ ṣe niwaju rẹ.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸRIN NI ADFENTI.

Adura.

OLUWA, gbé agbara rẹ dide, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o sì wá sinu wa, ki o sì fi agbara nla ràn wa lọwọ́; bi o sì ti ṣe pe, nitori ẹ̀ṣẹ ati ìwa buburu wa, a di ẹniti

Digitized by Google

adè li ọ̀na gidigidi, lati ma súre ije ti a da silẹ̀ niwaju wa, ki ore-ọfẹ́ ati ãnu rẹ̀ ti o pọ̀ju ki o ràn wa lọwọ́ nisisiyi, ki o sì gbà wa là; nitori itoye Ọmmọ rẹ̀ Oluwa wa, ẹniti ọ̀lá ati ogo wà fu pẹ̀lu iwọ ati Ẹmmí Mimọ́, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Episteli. Fil. 4. 4.

EMA yọ̀ nipa ti Oluwa nigba-gbogbo: mo sì tún wipe, Ẹ ma yọ̀. Ẹ jẹ ki ìwa pẹ̀lẹ nyin di mimọ̀ fu gbogbo awọn enia. Oluwa kùn si dèdẹ. Ẹ máṣe kọn-nu ohunkohun; ṣugbọn nipa adura ati èbẹ pẹ̀lu idupẹ, ẹ ma fi ìbere nyin hàn fu Ọlọrun li ohun gbogbo. Ati alafia Ọlọrun, ti o jù ìmọran gbogbo lọ, yio pa nyin li àiya ati ọkkàn mọ́ nipa Kristi Jesu.

Ihin-rere. Joh. 1. 19.

EYI sì li ẹrí ti Johanu, nigbati awọn Ju rán awọn alufa ati Lefite lati Jerusalemu wá lati bi i lẽre wipe, Tani iwọ ṣe? On sì jẹwọ́, kò sì sẹ́; ṣugbọn o jẹwọ́ wi fu wọn pe, Emi kì iṣe Kristi na. Nwọn sì bi i wipe, Tani iwọ ṣe? Iwọ ṣe Elia bi? O sì wipe Emi kì iṣe on. Iwọ ni woli ni bi? O sì dahùn wipe, Ndao. Nitorina nwọn wi fu u pe, Tani iwọ ṣe? ki awa ki o le fi èsin fu awọn ti o rán wa. Kili o wi niti iwọ tikararẹ? O wipe, Emi li Ohùn ẹni ti nkigbe ni ijù, Ẹ ṣe ki ọ̀na Oluwa tọ́, gẹ̀gẹ bi woli Isaia ti wi. Awọn ti a rán sì jẹ awọn ẹgbẹ Farisi. Nwọn sì bi i lẽre, nwọn wi fu u pe, Ẽha ti ṣe ti iwọ fi mbaptisi, bi iwọ kì iba ṣe Kristi na, tabi Elia, tabi woli ni? Johanu sì da wọn lohùn, wipe, Emi nfi omi baptisi: ṣugbọn ọkan duro larin nyin, ẹniti ẹnyin kò mọ̀; On na li, ẹniti mbọ̀ lẹhin mi, ti o pọ̀ju mi lọ, okùn bàta ẹṣẹ ẹniti emi kò yẹ

Digitized by Google

lati tú. Nkan nwọnyi li a ṣe ni Betabara loke odò Jordan, nibiti Johanu gbé mbaptisi wọn.

ỌJỌ TI IBÍ KRISTI, TI A NPÈ NI ỌJỌ

KRISTIMASI.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o fi Ọmmọ bíbi rẹ kanṣoṣo fu wa lati mu ẹda wa wọ, ati lati di bíbi ninu Wundia mimọ li akokò yi; Fifuni, bi a ti ntún wa da, ti a sì nsọ wa di ọmmọ rẹ nipa isọdọmmọ, ati nipa ore-ọfẹ, ki a le ma sọ wa di titun lọjọjọ nipa Ẹmmí Mimọ rẹ; nitori Jesu Kristi na Oluwa wa, ẹniti o wà ti o sì njọba pẹlu iwọ ati Ẹmmí na, lai Ọlọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Episteli. Heb. 1. 1.

OLỌRUN, ẹni, ni igba pupò ati li onirũru ìwa, ti o ti ipa awọn woli ba awọn babba sòrọ nigbani, li ọjọ ikẹhin wọnyi o ti ipasẹ Ọmmọkọnri rẹ ba wa sòrọ, ẹniti o fi jẹ arole ohun gbogbo, nipasẹ ẹniti o ti da awọn aiye pẹlu; ẹniti iṣe imọlẹ ti ogo rẹ, ati jijọ aworan ti ara rẹ, ti o sì nfi òrọ agbara rẹ dì ohun gbogbo mu, nigbati on tikararẹ ti wẹ ẹṣẹ wa nù, o joko li ọwọ ọtún ti ọlá nla li oke; niti a da a dara bẽ pọju awọn angeli lọ, nipa ijogún bi o sì ti ni orukọ titayọ jù wọn lọ. Nitoripe awọn angeli ewo li o wi nigba kan fu pe, Iwọ li Ọmmọkọnri mi, ọjọ oni ni mo bí ọ? Ati pẹlu, Emi ni yio ma ṣe Babba rẹ, on ni yio sì ma ṣe Ọmmọkọnri fu mi? Ati pẹlu, nigbati o mu akọbi ni wá si aiye, o ni, Ki gbogbo

Digitized by Google

awọn angeli Olọrun ki o sì ma foribalẹ fu u. Ati ni ti awọn angeli, o wipe, Ẹniti o da awọn angeli rẹ̀ li ẹmmí, ati awọn iranṣẹ rẹ̀ li ọwọ́ iná. Ṣugbọn fu Ọmmọkọnri li o wipe, Ité rẹ, Olọrun, lai ati lailai ni; ọpá alade ododo li ọpá alade ijọbba rẹ. Iwọ ti fẹ ododo, iwọ sì korira èṣẹ; nitorina Olọrun, ani Olọrun rẹ, li o ti ta oróro ayọ̀ si ọ lori jù awọn ẹgbẹ rẹ lọ. Ati Iwọ, Oluwa, lati ipilẹṣẹ li o ti fi idilẹ ti aiye sọlẹ; ati awọn ọrun ni iṣẹ ọwọ́ rẹ: nwọn yio parun; ṣugbọn iwọ mbẹ; gbogbo wọn ni yio sì di gbigbó bi aṣọ; ati bi agbada ni iwọ yio sì ma ká wọn, a o sì pàrọ wọn: ṣugbọn bakan na ni iwọ, ọdún rẹ kì yio sì pin.

Ihin-rere. Joh. 1. 1.

LI àtetekọṣe li Ọ̀rọ wà, Ọ̀rọ sì wà pẹlu Olọrun, Olọrun sì li Ọ̀rọ na. On na li o sì wà li àtetekọṣe pẹlu Olọrun. Lọwọ́ rẹ̀ li a sì ti da ohun gbogbo; lẹhin rẹ̀ kò sì si ohun kan ti o da ninu ohun ti a da. Ninu rẹ̀ ni ìye wà; ìye na sì ni imọlẹ araiye. Imọlẹ na sì nmọlẹ ninu òkunkun; òkunkun na kò sì mọ̀ ọ. Ọkọnri kan wà ti a rán lati ọdọ Olọrun wá, orukọ ẹniti jẹ Johanu. On na li a sì rán bi ẹlẽri, ki o le ṣe ẹlẽri fu Imọlẹ na, ki gbogbo awọn enia ki o le gbagbọ́ nipasẹ rẹ̀. On kì iṣe Imọlẹ na, ṣugbọn a rán a wá lati ṣe ẹlẽri fu Imọlẹ na. Eyi li ododo Imọlẹ, ti nmọlẹ fu gbogbo enia ti o wá si aiye. On sì wà li aiye, nipasẹ rẹ̀ li a sì ti da aiye, aiye kò sì mọ̀ ọ. O tọ̀ awọn ara ti rẹ̀ wá, awọn ara ti rẹ̀ kò sì gbà a. Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fu, lati di awọn ọmmọ Olọrun, ani awọn na ti o gbà orukọ rẹ̀ gbọ́: awọn ẹniti a bí, kì iṣe nipa ti ẹ̀jẹ́, tabi nipa ti ifẹ́ ara, bẽni

Digitized by Google

kì iṣe nipa ifé ti enia, bikoṣe nipa ifé, ti Ọlọrun. A sì sọ Ọrọ na di ara, on sì mba wa gbé, (awa sì nwò ogo rẹ̀, ogo ti o dabi ti ọmmọ bíbi kanṣoṣo ti Babba), ti o kún fu ore-ọfẹ ati otitọ.

ỌJỌ TI STEFANU.

Adura.

OLUWA, fifuni, ninu gbogbo ìjiya wa lori ilẹ aiye nihin nitori ẹrí otitọ rẹ, ki awa ki o le tẹ oju wa ṣinṣin mọ́ oke ọrun, ati nipa igbagbọ́, ki a ma wò ogo rẹ ti a o fi hàn; ati bi a ti nfi Ẹmmí Mimọ́ rẹ kún wa, ki a le ma kẹkọ bi ati fẹ, ti a sì ma sùre fu awọn oninunibini wa nipa apẹrẹ Stefanu mimọ́ aṣaju Ajẹri-kú rẹ, ẹniti o gbadura sọdọ rẹ Jesu olubukún, fu awọn olupa rẹ̀, iwọ ti o duro li ọwọ́ ọtún Ọlọrun lati ṣe iranlọwọ́ gbogbo awọn ti njìya nitori rẹ, Onilaja ati Alagbawi wa nikanṣoṣo. *Amin.*

Epistéli. Iṣe 7. 55.

STEPHEN li o kún fu Ẹmmí Mimọ́, o tẹjumọ, o nwò ọrun, o sì ri ogo Ọlọrun, ati Jesu o nduro li ọwọ́ ọtún Ọlọrun, o sì wipe, Wò o, mo ri ọrun o ṣí silẹ, ati Ọmmọ ọkọnri o nduro li ọwọ́ ọtún Ọlọrun. Nigbana ni nwọn kigbe soke li ohùn rara, nwọn sì dì eti wọn, nwọn fi ọkkàn kan rọ́ lù u, nwọn sì wọ́ ọ sẹhin ode ilu nla na, nwọn sọ ọ li okuta: awọn ẹlẹri sì fi aṣọ wọn lelẹ lẹba ẹsẹ ọmmọkọnri kan ti a npè ni Saulu. Nwọn sọ Stefanu li okuta, o npè Ọlọrun, o sì nwipe, Jesu Oluwa, gbà ẹmmí mi. Nigbati o sì kunlẹ, o kigbe li ohùn rara pe, Oluwa, má kà ẹṣẹ yi si wọn li ọrùn. Nigbati o sì wi eyiyi, o sùn.

Digitized by Google

Ihin-rere. Mat. 23. 34.

KIYESI i, emi o rán awọn woli, ati amoye enia, ati akọwe si nyin : omiran ninu wọn li ẹnyin o pa, ti ẹnyin o sì kàn mọ́ agbelebu; ati omiran ninu wọn li ẹnyin o nà ni sinagogu nyin, ati ti ẹnyin o ṣe inunibini si lati ilu de ilu: ki gbogbo ẹ̀jẹ ti awọn olõtọ, ti a ti ta silẹ li aiye, ki o ba le wà li ori nyin, lati igba ẹ̀jẹ Abeli olõtọ wá fi de ẹ̀jẹ Sakaria, ọmmọkọnri Barakia, ẹniti ẹnyin pa larin tempeli ati pẹpẹ. Lõtọ ni mo wi fu nyin, Gbogbo nkan wọnyi ni yio wá sori iran yi. Jerusalemu, Jerusalemu, iwọ ti o pa awọn woli, ti o sì sọ okuta lù awọn ti a rán si ọ pa, nigba melo li emi nfẹ iradọ bò awọn ọmmọ rẹ, bi agbebọ̀ ti iradọ bò awọn ọmmọ rẹ̀ labbẹ apa rẹ̀, ṣugbọn ẹnyin kò fẹ! Sawò o, a fi ile nyin silẹ fu nyin li ahoro. Mo sá wi fu nyin, Ẹnyin kì yio ri mi mọ́ lati isisiyi lọ, titi ẹnyin o fi wi pe, Olubukún li ẹniti o mbọ̀ wá li orukọ Oluwa.

ỌJỌ TI JOHANU EFANGELISTI.

Adura.

OLUWA alãnu, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ rán ìtan imọlẹ titàn-ṣan rẹ sara Ijọ awọn enia rẹ, niti a nṣe imọlẹ si i nipa ẹkọ́ ti Aposteli ati Efangelisti rẹ Johanu mimọ́ olubukún, ki awa ki o ma rìn bẹ̃ nipa imọlẹ otitọ rẹ, nigbọṣe titi, ki o le di imọlẹ ìye alànipẹkun, nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1. Joh. 1. 1.

EYITI o ti wà li àtetekọṣe, ti awa ti gbọ́, ti awa ti fi oju wa ri, ti awa sì ti tẹiumọ wò,

Digitized by Google

ti ọwọ́ wa sì dìmu, niti Ọ̀rọ̀ lye; (nitoriti lye ti farahàn, awa sì ri i, awa sì jẹri, awa sì sọ lye alnipẹkun na fu nyin, ti o ti mbẹ pẹlu Babba, ti o sì farahàn fu wa;) Eyiti awa ti ri, ti awa sì ti gbọ́, li awa nsọ fu nyin, ki ẹnyin pẹlu ki o le ni ìdapọ pẹlu wa: ati nitõtọ ìdapọ wa mbẹ pẹlu Babba, ati pẹlu Jesu Kristi Ọmmọ rẹ̀. Nkan wọnyi li awa kọwe si nyin, ki ayọ̀ nyin ki o le kún. Njẹ eyi ni ọ̀rọ̀ ti awa ti gbọ́ lọdọ rẹ̀, ti awa sì sọ fu nyin, pe imọlẹ li Ọlọrun, ati pe òkunkun kò si lara rẹ̀ rara. Bi awa ba wipe awa ni ìdapọ pẹlu rẹ̀, ti awa sì nrìn li òkunkun, awa nṣeke, awa kò sì ṣe otitọ: ṣugbọn bi awa ba nrìn ninu imọlẹ, bi on ti mbẹ ninu imọlẹ, awa ni ìdapọ pẹlu ara wa, ati ẹ̀jẹ ti Jesu Kristi Ọmmọ rẹ̀ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa gbogbo. Bi awa ba wipe awa kò li ẹ̀ṣẹ, awa tàn ara wa jẹ, otitọ kò sì si ninu wa. Bi awa ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ ati olododo li on lati dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa, ati lati wẹ̀ wa nu kuro ninu alṣodododo gbogbo. Bi awa ba wipe awa kò ṣẹ̀, awa mu u li eke, ọ̀rọ̀ rẹ̀ kò sì si ninu wa.

Ihin-rere. Joh. 21. 19.

JESU wi fu Peteru pe, Ma tọ̀ mi lẹhin. Peteru sì yipada, o ri ọmmọ ẹhin ni, ẹniti Jesu fẹ mbọ̀ lẹhin; ẹniti o fi ori tì i li õkanàiya nigba onjẹ alẹ, ti o sì wi fu u pe, Oluwa, tali ẹniti o fi ọ hàn? Nigbati Peteru ri i, o wi fu Jesu pe, Oluwa, kili eleyi yio ha ṣe? Jesu wi fu u pe, Bi emi ba fẹ pe, ki o duro titi emi o fi de, kili eyini fu ọ? iwọ sá ma tọ̀ mi lẹhin. Nigbana li ọ̀rọ̀ yi tàn kalẹ kiri ninu awọn arakọnri pe, ọmmọ ẹhin ni kì yio kú: ṣugbọn Jesu kò wi fu u pe, On kì yio kú; ṣugbọn Bi emi ba fẹ pe ki o duro titi emi

Digitized by Google

o fi de, kili eyini fu ọ? Eyi sì li ọmmọ ẹhin na, ẹniti o jẹ̀ri nkan wọnyi, ti o sì kọwe nkan wọnyi: awa sì mọ̀ pe otitọ li ẹrí rẹ̀. Ati ỳpọlọpọ ohun omiran pẹlu ni Jesu ṣe, eyiti bi a ba kọwe gbogbo wọn, mo rò pe aiye papa kò le gbà iwe na ti a ba kọ.

ỌJỌ TI ALAÌṢẸ-ALAÌRỌ.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, lati ẹnu awọn ọmmọ ọwọ́ ati ọmmọ ọmu iwọ ti o làna agbara silẹ, ti o sì mu awọn ọmmọ ọwọ́ yìn ọ logo nipa ikú wọn; Ṣe pọnju ki o sì ṣe apakú gbogbo ìwa èṣẹ ninu wa, ki o sì mu wa lara le nipa ore-ọfẹ rẹ, pe nipa alṣẹ-alrọ ìwa wa, ati nipa iduro ṣinṣin igbagbọ́ wa titi di ikú, ki awa ki o le ma yìn Orukọ mimọ́ rẹ logo; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Ifihan 14. 1.

MO sì wò, sì kiyesi i, Ọdọ Agutan kan duro lori òke Sion, ati pẹlu rẹ̀ ọkẹ́ meje o le ẹgbaji enia, nwọn ni orukọ Babba rẹ̀ ti a kọ si iwaju wọn. Mo sì gbọ́ ohùn kan lati ọrun wá, bi iró omi pupọ̀, ati bi sisán ãrá nla: mo sì gbọ́ ohùn ti awọn aludùru, nwọn nlù dùru wọn: nwọn sì nkọn bi ẹnipe orin titun niwaju itẹ́ ni, ati niwaju awọn ẹda mẹrin ni, ati awọn alàgba ni: kò sì si ẹniti o le kọ́ orin na, bikoṣe awọn ọkẹ́ meje o le ẹgbaji enia, ti a rà pada lori ilẹ aiye. Awọn wọnyi li a kò fi obiri sọdi ẽri; nitoripe wundia ni nwọn. Awọn wọnyi ni ntọ̀ Ọdọ Agutan ni lẹhin nibikibi ti nrè. Awọn wọnyi li a rà pada ninu awọn enia, nwọn jẹ eso akọso fu Ọlọrun

Digitized by Google

ati fu Ọdọ Agutan. A kò sì ri ẹ̀tan li ẹnu wọn: nitoriti nwọn wà li alleṣẹ niwaju itẹ́ Ọlọrun.

Ihin-rere. Mat. 2. 13.

ANGELI Oluwa yọ si Josefu li oju alá, o wipe, Dide, gbé ọmmọ titun ni pẹlu iya rẹ̀, ki o sálọ si Egipti, ki iwọ ki o sì gbé ibẹ̀ titi emi o fi sọ fu ọ; nitoriti Herodu ngbèro ati wá ọmmọ titun na lati pa a. Nigbati o sì dide, o mu ọmmọ titun ati iya rẹ̀ li oru, o sì lọ si Egipti; o sì wà nibẹ̀ titi o fi di igba ikú Herodu, ki eyi ti a wi niti Oluwa lati ẹnu woli ni ki o le ṣẹ, pe, Ni Egipti ni mo ti pè ọmmọ mi jade wá. Nigbati Herodu ri pe, on di ẹni ẹ̀tan lọdọ awọn amoye, o binu gidigidi, o sì ranṣẹ, o sì pa gbogbo awọn ọmmọ ọwọ́ ti o wà ni Betlehemu ati ni ẹkùn rẹ̀, lati awọn ọmmọ ọdún meji mọ abikẹhin wọn, gẹgẹ bi akokò ti o ti bère lẹsọlẹsọ lọwọ́ awọn amoye na. Nigbana li eyi ti a ti wi tẹlẹ lati ẹnu woli Jeremia ṣẹ, pe, Ni Rama ni a gbọ́ ohùn, ohùn rere, ati ẹkún, ati ọ̀fọ nla, Rakeli nsọkun awọn ọmmọ rẹ̀, kò gbipẹ, nitoriti nwọn kò si.

ỌJỌ ỌLỌRUN TI O TẸ̀LE ỌJỌ TI IBÍ KRISTI.

Adura.

ỌLỌRUN Olodumare, iwọ ti o fi Ọmmọ bíbi rẹ kanṣoṣo fu wa lati mu ẹda wa wọ́, ati lati di bíbi ninu Wundia mimọ́ li akokò yi; Fifuni bi a ti ntún wa da, ti a sì nsọ wa di ọmmọ rẹ nipa isọdọmmọ, ati nipa ore-ọfẹ, ki a le ma sọ wa di titun lọjọjọ nipa Ẹmmí Mimọ́ rẹ; nitori Jesu Kristi na Oluwa wa, ẹniti o

Digitized by Google

wà ti o sì njọbba pẹlu iwọ ati Ẹmmí na, lai Ọlọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Epistéli. Gal. 4. 1.

NJẸ mo ni, Arole na, niwọn igbati o ba wà li ewe, kò yàtọ si ọmmọ ọdọ, bi on tilẹ jasi oluwa gbogbo wọn; ṣugbọn o wà labbẹ olukọ́ ati olutọju titi fi di akokò ti babba ti yàn tẹlẹ. Gẹgẹ bẹ̃ sì li awa, nigbati awa ti wà li ewe, awa ti wà li ondè labbẹ ipilẹṣẹ ẹda: ṣugbọn nigbati akokò kíkun na de, Ọlọrun rán Ọmmọ rẹ̀ jade, ẹniti a bí ninu obiri, ti a bí labbẹ ofin, lati da awọn ti mbẹ labbẹ ofin ni ìde, ki awa ki o le gbà isọdọmmọ awọn ọmmọ ni. Ati nitori ti ẹnyin iṣe ọmmọkọnri, Ọlọrun sì ti rán Ẹmmí Ọmmọ rẹ̀ wá si nyin li àiya, ti nkigbe wipe, Aba, Babba. Nitorina iwọ kì iṣe ọmmọ ọdọ mọ́, bikoṣe ọmmọkọnri; ati bi iwọ iba iṣe ọmmọkọnri, njẹ iwọ di arole Ọlọrun nipa Kristi.

Ihin-rere. Mat. 1. 18.

BI ibí Jesu Kristi ti ri ni: li akokò ti a fẹ Maria iya rẹ̀ fu Josefu, ki nwọn to pade, a ri i, o lóyun lati ọwọ́ Ẹmmí Mimọ́ wá. Nigbana ni Josefu ọkọ rẹ̀, ti ṣe olõtọ enia, kò fẹ fi i kìlọ ni gbangba, o fẹ ikọ̀ ọ silẹ ni ìkọkọ. Ṣugbọn nigbati o nrò nkan wọnyi, wò o, angeli Oluwa yọ si i li oju alá, o wipe, Josefu, iwọ ọmmọ Dafidi, má fòya lati mu Maria aya rẹ̀ si ọdọ; nitori eyi ti o yún ninu rẹ̀, lati ọwọ́ Ẹmmí Mimọ́ ni. Yio sì bí ọmmọkọnri, Jesu ni iwọ yio pè orukọ rẹ̀: nitori on ni yio gbà awọn enia rẹ̀ là kuro ninu èṣẹ wọn. Gbogbo nkan wọnyi sì ṣe, ki eyi ti a ti wi tẹlẹ lati ọdọ Oluwa wá li ẹnu woli ni ki o le ṣẹ, pe, Kiyesi i, wundia kan yio lóyun, yio bí ọmmọkọnri

Digitized by Google

kan, ṅwọn o ma pè orukọ rẹ ni Emanueli, ni itumọ rẹ, Ọlọrun wà pẹlu wa. Nigbati Josefu dide ninu orun rẹ, o ṣe bi angeli Oluwa ti wi fu u, o sì mu aya rẹ sì ọdọ: On kò sì mọ ọ titi o fi di igba ti o bí akọbi rẹ ọmmọkọnri: ti o sì pè orukọ rẹ ni Jesu.

IKỌLA TI KRISTI.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o ṣe atikọla Ọmmọ rẹ olubukún, ti o sì mu u pa ofin mọ́ nitori enia; Fi Ikọla otitọ ti Ẹmmí fu wa; bi a ti npọn àiya wa, ati gbogbo awọn èya ara wa loju, kuro ninu ifẹ-kufẹ aiye ati ti ara, ninu ohun gbogbo ki awa ki o lè ma gbà ifẹ́ rẹ gbọ́ ti o ni ibukún; nipasẹ Ọmmọ rẹ na Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Epistéli. Rom. 4. 8.

IBUKÚN ni fu ọkọnri na ẹniti Oluwa kò kà èṣẹ rẹ si li ọrùn. Ibukún yi ha wá fu awọn akọla nikan ni, tabi fu awọn alaìkọla pẹlu? nitoriti a wipe, a kà igbagbọ́ si Abrahamu fu ododo. Bawo li a ha kà a si i? nigbati o wà ni ikọla tabi li aìkọla? Kì iṣe ni ikọla, ṣugbọn bikoṣe li aìkọla ni. O sì gbà àmi ikọla, èdidi iṣẹ ti ododo igbagbọ́ ti o ni nigbati o wà li aìkọla: ki o le ṣe babba gbogbo awọn ti o gbagbọ́, bi a kò tilẹ kọ wọn ni ilà; ki a le kà ododo si wọn pẹlu: Ati babba ikọla fu awọn ti kò si ninu kìki awọn akọla nikan, ṣugbọn ati ti awọn ti nrìn nipasẹ igbagbọ́ Abrahamu babba wa, ti o ni li aìkọla. Nitori ileri fu Abrahamu tabi fu irú ọmmọ rẹ pe, on yio ṣe arole aiye, kì iṣe nipa ofin,

Digitized by Google

ṣugbọn bikoṣe nipa ododo igbagbọ́. Nitori bi awọn ti nṣe ti ofin ba ṣe arole, igbagbọ́ di asan, ileri sì di alailli agbara.

Ihin-rere. Luku 2. 15.

OSÌ ṣe, nigbati awọn angeli na ti pada kuro lọdọ wọn lọ si ọrun, awọn ọkọnri oluṣọ agutan na ba ara wọn sọ pe, Ẹ jẹ ki a lọ si Betlehemu tàra, ki a le ri ohun ti ó ṣẹ, ti Oluwa fihàn fu wa. Nwọn sì wá lọgan, nwọn sì ri Maria, ati Josefu, ati ọmmọ ọwọ́ na, o dubulẹ ninu ibujẹ ẹran. Nigbati nwọn sì ti ri i, nwọn rò ihin na kiri ti a ti wi fu wọn nidi ti ọmmọ yi. Ẹnu sì yà gbogbo awọn ti o gbọ́ si nkan wọnyi, ti a ti wi fu wọn lati ọdọ awọn oluṣọ agutan wá. Ṣugbọn Maria sì pa gbogbo nkan wọnyi mọ́, o sì nrò wọn ninu ọkkàn rẹ̀. Awọn oluṣọ agutan sì pada lọ, nwọn nfi ogo fu Ọlọrun, nwọn sì nyìn i; nitori ohun gbogbo ti nwọn ti gb̀ọ́ ati ti nwọn ti ri, bi a ti wi i fu wọn. Nigbati ijọ ękẹjọ sì pé lati kọ ọmmọ na nila, nwọn pè orukọ rẹ̀ ni JESU, bi a ti sọ ọ tẹlẹ lati ọdọ angeli na wá ki a to lóyun rẹ̀ ninu.

IFIHÀN,

TÀBI IFIHÀN KRISTI FU AWỌN KEFERI.

Adura.

OLỌRUN, nipa iṣetọna ti irawọ́ kan, iwọ ti o fi Ọmmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo hàn fu awọn Keferi li atijọ; Awa nfi irẹlẹ ohùn bẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ̀, ki iwọ ki o sì fi Jesu Kristi ọmmọ rẹ̀ hàn nisisiyi fu gbogbo awọn Keferi li aiye; nipa Ẹmmí mimọ́ ati ọ̀rọ otitọ rẹ̀; fi ore-ọfẹ̀ fu wọn; ki nwọn ki o le wá sọdọ rẹ̀

Digitized by Google

ni igbagbó, lati fi iyìn fu u, ati lati ri igbala gbà nipasẹ rẹ; Fi ãnu rẹ fifuni, ki awa, ti o ti ipa igbagbó mọ ọ nisisiyi, lẹhin aiye yi, ki a le ma ni eso ọya-ori Ọlọrun ti o li ogo; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Epistéli. Efes. 3. 1.

NITORI eyina, emi Paulu, ondè Jesu Kristi na fu ẹnyin Keferi, bi ẹnyin ba ti gburó iṣẹ ipinfuni ti ore-ọfẹ Ọlọrun, ti a fifu mi si nyin: Bi o ti ṣepe nipa iṣipaya li o ti fi òrọ ijinlẹ ni hàn fu mi; (gẹgẹ bi mo ti kọwe òrọ diẹ nitiṣaju, nigbati ẹnyin ba kà a, nipasẹ eyi ti ẹnyin o fi moye ìmo mi ninu òrọ ijinlẹ Kristi,) eyiti a kò ti fihàn awọn ọmmọ enia ri lati irandiran omiran gbogbo, gẹgẹ bi a ti fi wọn hàn nisisiyi fu awọn Aposteli ati awọn woli mimó nipa ti Ẹmmí; Ki awọn Keferi ki o le di àjumọjogun, ki nwọn ki o sì le di ara kan na, ati alabapin ti ileri rẹ ninu Kristi nipa Ihín rere: nipasẹ eyiti a fi mi ṣe iranṣẹ, gẹgẹ bi èbun ti ore-ọfẹ Ọlọrun ti a fifu mi, nipa iṣẹ agbara rẹ. Ani fu emi, ẹniti o kerejù ọmmọ ẹhin ninu gbogbo awọn enia mimó, li a fi ore-ọfẹ yi fu, ki emi ki o le ma wasu awamáridi òpọlọpọ ọrò ti Kristi larin awọn Keferi; ati lati fihàn gbogbo awọn enia ohun ti ìdapọ ti òrọ ijinlẹ na jasi, eyiti a ti fi pamó lọdọ Ọlọrun lati igba ọjọ ìwa, ẹniti o da ohun gbogbo nipa Jesu Kristi: nitori nisisiyi ki a le fi òpọlọpọ onirũru ọgbọn Ọlọrun hàn fu awọn ijoye ati awọn alagbara ti mbẹ li ọrun nipa ijó awọn enia Ọlọrun. Gẹgẹ bi ipin-nu alnipẹkun na ti o ti pin-nu ninu Kristi Jesu Oluwa wa: Nipasẹ ẹniti awa ti ni igboiya, ati òna pẹlu igbẹkẹle nipa igbagbó lọdọ rẹ.

Digitized by Google

Ihin-rere. Mat. 2. 1.

NIGBATI a sì bí Jesu ni Betlehemu ti Juda, nigba aiye Herodu ọba, kiyesi i, awọn amoye kan ti ìha ìla õrùn wá si Jerusalemu, Nwọn mbère wipe, Nibo li ẹniti a bí ti ṣe ọba awọn Ju wà? nitori awa ti ri irawọ rẹ̀ ni ìha ìla õrùn, awa sì wá lati foribalẹ fu u. Nigbati Herodu ọba sì ti gbọ́ nkan wọnyi, ara rẹ̀ kò lelẹ, ati gbogbo awọn ara Jerusalemu pẹlu rẹ̀. Nigbati o sì pè gbogbo awọn olori alufa ati awọn akọwe enia, o bi wọn lẽre pe, nibo li a o gbé bí Kristi. Nwọn sì wi fu u pe, Ni Betlehemu ti Judea ni: nitori bẽli a kọwe rẹ̀ lati ọwọ́ woli ni wá, Iwọ Betlehemu ni ilẹ Juda, iwọ kì iṣe kekere ninu awọn ọmọ alade Juda, nitori lati inu rẹ̀ ni Bãlẹ kan yio ti jade, ti yio jọba Israeli awọn enia mi. Nigbati Herodu pè awọn amoye na si ìkọkọ, o bi wọn lẹsọlẹsọ lakokò igbati irawọ na hàn. O sì rán wọn lọ si Betlehemu, o wipe, Ẹ lọ, wá ọmọ titun na li awari; nigbati ẹnyin ba sì ri i, ẹ pada wá sọ fu mi, ki emi ki o le wá iforibalẹ fu u pẹlu. Nigbati nwọn sì gbọ́ ti ọba, nwọn sì dide; sì wò o, irawọ ti nwọn ti ri lati ìha ìla õrùn wá, o ṣaju wọn, titi o fi wá iduro loke ibi ti ọmọ titun na gbé wà. Nigbati nwọn sì ri irawọ na, nwọn yọ̀ ayọ̀ nlanla. Nigbati nwọn sì wọ̀ ile, nwọn ri ọmọ titun na pẹlu Maria iya rẹ̀, nwọn wolẹ, nwọn sì foribalẹ fu u: nigbati nwọn sì tú iṣura wọn, nwọn ta a lọrẹ, wura, ati turari, ati ojia. Bi Ọlọrun ti kìlọ fu wọn li oju alá pe, ki nwọn ki o máṣe pada tọ̀ Herodu lọ mọ́, nwọn gbà ọna omiran lọ si ilu wọn.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN EKINI LẸHIN IFIHÀN.

Adura.

OLUWA, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi ãnu gbà adura awọn enia rẹ ti nkepè ọ; ki iwọ ki o sì fifuni pe ki nwọn ki o ma woye, ati ki nwọn ki o sì ma mọ ohun ti nwọn iba ma ṣe, ati pẹlu ki nwọn ki o le ma ni ore-ọfẹ ati agbara lati ma pa eyi na mọ nitõtọ; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Rom. 12. 1.

NITORINA mo fi iyọnu Ọlọrun bẹ nyin, arakọnri, ki ẹnyin ki o le fi ara nyin ru ẹbọ ãye, mimọ, itẹwọgbà fu Ọlọrun, eyini ni iṣe sisìn nyin ti o jana. Ki ẹnyin ki o má sì da ara nyin pọ mọ aiye yi: ṣugbọn ki ẹnyin ki o parada lati di titun ninu nyin, ki ẹnyin ki o le ri idi ifẹ Ọlọrun, ti o dara, ti iṣe itẹwọgbà, ti o sì pé. Njẹ mo wi fu olukuluku enia ti o wà ninu nyin, nipa ore-ọfẹ ti a fifu mi, ki o má rò jù bi o ti yẹ ni rirò lọ; ṣugbọn ki o le rò niwọntunwọnsìn, bi Ọlọrun ti fi ìwọn igbagbọ́ fu olukuluku. Nitori gẹgẹ bi awa ti li ẹ̀ya pipọ li ara kan, ti gbogbo ẹ̀ya kò sì ni iṣẹ kan na: bẹ̃li, awa, pipọ, a ṣe ara kan lara Kristi, olukuluku sì ṣe ẹ̀ya ara ọmmọnikeji rẹ̀.

Ihin-rere. Luku 2. 41.

AWỌN õbi rẹ a sì ma lọ si Jerusalemu li ọdọdún si ijọ ọdún irekọja. Nigbati o sì di ọmmọ ọdún mejila, nwọn goke lọ si Jerusalemu gẹgẹ bi iṣe ti ijọ ọdún na. Nigbati nwọn sì pé ọjọ wọn, bi nwọn ti npada bọ, ọmmọ na Jesu duro lẹhin ni Jerusalemu; ati Josefu ati iya rẹ kò mọ. Ṣugbọn nwọn ṣebi

Digitized by Google

o wà li ẹgbẹ ère, o rìn ìrin ọjọ kan; nwọn wá a kiri ninu awọn ara ati awọn ojulumọ wọn. Nigbati nwọn kò sì ri i, nwọn tún pada si Jerusalemu, nwọn nwá a kiri. O sì di igbati o ṣe, ni ijọ ẹkẹta nwọn ri i ninu tempeli (ile Ọlọrun,) o joko li arin awọn olukọni, o ngbọ́ ti wọn, o sì mbi wọn lẽre. Ẹnu sì yà gbogbo awọn ti o gbọ́ ọrọ rẹ̀ li oyé ati idahùn rẹ̀. Nigbati nwọn sì ri i, hà ṣe wọn: iya rẹ̀ sì bi i pe, Ọmmọkọnri, ẽṣe ti iwọ fi ṣe wa bẽ? sawò o, babba rẹ ati emi ti nfi ibinujẹ wá ọ kiri. O sì dahùn wi fu wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi nwá mi kiri? ẹnyin kò mọ̀ pe, emi kò le ṣe ki emi má wà nibi iṣẹ babba mi? Ọrọ ti o sọ kò sì yé wọn. O sì ba wọn sọkalẹ lọ si Nasareti, o sì fi ara balẹ fu wọn: ṣugbọn iya rẹ̀ pa gbogbo nkan wọnyi mọ́ ninu ọkkàn rẹ̀. Jesu sì pọ̀ li ọgbọ́n, o sì ndàgba, o sì wà li oju rere li ọdọ Ọlọrun ati enia.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKEJI LẸHIN IFIHÀN.

Adura.

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun iwọ ti o njọbba ohun gbogbo li ọrun ati li aiye; Fi ãnu gbọ́ ẹbẹ awọn enia rẹ, ki o sì fi alafia rẹ fu wa li ọjọ aiye wa gbogbo; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Rom. 12. 6.

NJẸ bi awa sì ti nri ọ̀tọ-ọ̀tọ ẹbun gbà bi ore-ọfẹ ti a fifu wa, bi o ṣe isọtẹlẹ ni, ki awa ki o ma ṣe sọtẹlẹ ni ìwọn igbagbọ́; tabi iṣẹ alufa, ki a ma kọjusi iṣẹ alufa wa: tabi ẹniti nkọ́ni, ki o kọjusi kíkọ; tabi ẹniti o ngbàni niyanju, si igbiyanju: ẹniti o nfi funi,

Digitized by Google

ki o ma fi inu kan ṣe e; ẹniti nṣe olori, ki o ma ṣe e li oju mejeji; ẹniti nṣãnu, ki o ma fi inu didùn ṣe e. Ki ifẹ ki o wà li alṣẹtan. Ẹ takéte si ohun ti o ṣe buburu; ẹ fi ara mọ ohun ti o ṣe rere. Ẹ ma fi inu rere fẹ ara nyin ni ifẹ arakọnri; ni ti ọllá, ẹ ma fi iyìn fu ọmmọnikeji nyin; ẹ máṣe imẹlẹ ni iṣẹ iṣe; ni igbona ọkkàn; ẹ ma sìn Oluwa; ẹ ma yọ ni ireti; ẹ ma mu sũru ninu ipọnju; ẹ ma duro gangan si adura igbà; ẹ ma pín fu alàni ti awọn enia mimọ; fi ara nyin fu alejò iṣe. Ẹ ma sùre fu awọn ti nṣe inunibini si nyin: ẹ ma sùre, ẹ má sì ṣepè. Awọn ti nyọ ki ẹnyin ki o ma ba wọn yọ, awọn ti nsọkun ki ẹnyin ki o ma ba wọn sọkun. Ki ẹnyin ki o wà ni inu kan na si ara nyin. Ẹ máṣe tọju ohun giga, ṣugbọn ki ohun ti kò niyìn ki o kún nyin loju.

Ihin-rere. Joh. 2. 1.

NI ijọ ẹkẹta a nṣe igbeyawo kan ni Kana ti Galili; iya Jesu sì mbẹ nibẹ: a sì pè Jesu ati awọn ọmmọ ẹhin rẹ pẹlu, si ibi igbeyawo. Nigbati nwọn sì ṣe alaini ọti wain, iya Jesu wi fu u pe, Nwọn kò li ọti wain. Jesu wi fu u pe, Kini si mi pẹlu iwọ obiri yi? wakati mi kò ti ide. Iya rẹ sì wi fu awọn iranṣẹ pe, Ohunkohun ti o ba wi fu nyin, ẹ ṣe e. Ikoko okuta omi mẹfa li a sì gbé kalẹ nibẹ, gẹgẹ bi iṣe ìwẹnù ti awọn Ju, ọkọkan nwọn gbà to ìwọn ladugbo meji tabi mẹta. Jesu wi fu wọn pe, Ẹ pọn omi kún ikoko wọn-ni. Nwọn sì kún wọn titi de eti. O sì wi fu wọn pe, Ẹ bù u jade nisisiyi, ki ẹ sì gbé e tọ olori àse lọ. Nwọn sì gbé e lọ. Nigbati olori àse sì ti tọ omi ti a sọdi ọti wain wò, ti kò sì mọ ibi ti a gbé ti mu u

Digitized by Google

wá: (bikoṣe awọn iranṣẹ ti o pọn omi na wá li o mọ̀;) olori àse pè ọkọ iyawo, o sì wi fu u pe, Olukuluku enia li àtetekọṣe a ma gbé ọti wain rere kalẹ; nigbati awọn enia ba sì mu yó tan, nigbana ni imu eyi ti kò dara bayi wá: ṣugbọn iwọ pa ọti wain rere na mọ́ titi o fi di isisiyi. Eyi li àtetekọṣe iṣẹ iyanu Jesu ni Kana ti Galili, o sì fi ogo rẹ̀ hàn jade; awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ sì gbà a gbọ́.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸTA LẸHIN IFIHÀN.

Adura.

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, fi ãnu wò allera wa nwọnyi, ati ninu ewu ati alni wa gbogbo, nà ọwọ́ ọtún rẹ jade lati ṣe iranlọwọ́ ati lati dãbobo wa; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Rom. 12. 16.

ẸMÁṢE ọlọ́gbọn li oju ara nyin. Ẹ má fi buburu gbẹsan buburu fu ẹnikẹni. Ẹ ma pèse ohun ti o tọ́ li oju awọn enia gbogbo. Bi o le ṣe, bi o ti wà ni ipa nyin, ẹ ma fi alafia ba gbogbo awọn enia gbé. Olufẹ ọwọn, ẹ máṣe gbẹsan fu ara nyin, ṣugbọn ẹ fi àye silẹ fu ibinu: nitoriti a kọ ọ pe, Oluwa wipe, Ẹsan ni ti emi; emi o gbẹsan. Nitorina bi ebi ba npa ọtá rẹ, fu u li onjẹ; bi ongbẹ ba ngbẹ ẹ, fu u li ohun mimu: ni ṣiṣe bẹ̃ iwọ o kó oguna jọ si i li ori. Ki a má fi buburu ṣẹgun rẹ, ṣugbọn fi rere ṣẹgun buburu.

Ihin-rere. Mat. 8. 1.

NIGBATI o ti ori òke sọkalẹ, ọpọ awọn enia nwọ tọ̀ ọ lẹhin. Sì wò o, adẹtẹ kan

Digitized by Google

wá, o ntẹriba fu u, o wipe, Oluwa, bi iwọ ba fẹ, iwọ le sọ mi di mimọ́. Jesu sì nà ọwọ́ rẹ̀, o fi bà a, o wipe, Mo fẹ; iwọ di mimọ́. Lojukan na ẹ̀tẹ rẹ̀ sì mọ́. Jesu sì wi fu u pe, Wò o, máṣe sọ fu ẹnikan; ṣugbọn ma ba ọ̀na rẹ lọ, fi ara rẹ hàn fu awọn alufa, ki o sì bun ẹ̀bun rẹ ẹrí fu wọn, bi Mose ti sọ ọ li ofin. Nigbati Jesu sì wọ̀ Kapernaumu, ibalogun ọ̀rún kan tọ̀ ọ wá, o mbẹ̀ ẹ, o sì nwipe, Oluwa, ọmmọ ọdọ mi dubulẹ arun ẹ̀gba ni ile, ni irora pupọ̀. Jesu sì wi fu u pe, Emi mbọ̀ wá mu u lara da. Ibalogun ọ̀rún na dahùn, o sì wipe, Oluwa, Emi kò yẹ ti iwọ iba fi wọ̀ abbẹ orule mi; ṣugbọn sọ kìki ọ̀rọ kan, a o sì mu ọmmọ ọdọ mi lara da. Ẹniti o wà labbẹ oloyè sá li emi, emi sì li ọmmọ ogun lẹhin mi; Mo wi fu ẹnikan pe, Lọ, a sì lọ; ati fu ẹnikeji pe, Wá, a sì wá; ati fu ọmmọ ọdọ mi pe, Ṣe eyi, a sì ṣe e. Nigbati Jesu sì gbọ́, ẹnu yà a, o sì wi fu awọn ti o ntọ̀ ọ lẹhin pe, Lõtọ ni mo wi fu nyin, emi kò ri igbagbọ́ nla bi irú eyi ninu awọn enia Israeli. Mo sì wi fu nyin, Ọpọlọpọ enia ni yio ti ìha ìla õrùn ati ìha ìwọ õrùn wá, nwọn yio sì ba Abrahamu, ati Isãki, ati Jakobu joko ni ijọ̀bba ọ̀run. Ṣugbọn awọn ọmmọ ijọ̀bba li a o sọ sinu òkunkun biribiri, ọhun nibẹ̀ ni nwọn yio ma sọkun, ti nwọn yio sì ma pa ehin keke. Jesu sì wi fu ibalogun ọ̀rún na pe, Ma ba ọ̀na ti rẹ lọ, bi iwọ sì ti gbagbọ́, bẹ̃ni ki o ri fu ọ. A sì mu ọmmọ ọdọ rẹ̀ lara da ni wakati kan na.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸRIN LẸHIN IFIHÀN.

Adura.

ỌLỌRUN, iwọ ti o mọ̀ pe a dè wa si arin ọ̀pọlọpọ ati ewu nla, pe nitori idi allera

Digitized by Google

ẹda wa, awa kò le duro ṣinṣin nigba-gbogbo; Fi irú agbara ati àbo bẹ́ fu wa, ti yio ma tì wa lẹhin ninu ewu gbogbo, ti yio sì ma rù wa kọjaidanwò gbogbo; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Rom. 13. 1.

KI olukuluku ọkkàn ki o foribalẹ fu agbara ti o jù u. Nitoriti kò si agbara kan, bikoṣe lati ọdọ Ọlọrun wá: gbogbo agbara ti o wà lati ọdọ Ọlọrun li ati làna rẹ̀ wá. Njẹ ẹniti o ba tapá si agbara, o tapá si ìlana Ọlọrun: awọn ẹniti o ba sì ntapá, nwọn o gbà ẹbi fu ara wọn. Nitoriti awọn ijoye kì iṣe èru si iṣẹ rere, bikoṣe si iṣẹ buburu. Njẹ iwọ kì yio bèru agbara? ṣe eyi ti o dara, iwọ o sì gbà iyìn lọdọ rẹ̀ na: nitori iranṣẹ Ọlọrun ni iṣe fu iwọ si rere. Ṣugbọn bi iwọ ba ṣe buburu, ma bèru; nitoriti kò rù idà oyè na lasan: nitori iranṣẹ Ọlọrun ni iṣe, olugbẹsan lati ṣiṣẹ ibinu si ara awọn ẹniti nṣe buburu. Nitorina ẹnyin kò gbọdọ ṣàlma tẹriba, kì iṣe nitori ti ibinu nikan, ṣugbọn nitori ìmọninu pẹlu. Nitori eyi na ẹ ma san owo ode pẹlu: nitori iranṣẹ Ọlọrun ni nwọn, eyiyi na ni nwọn mbojuto nigba-gbogbo. Njẹ ẹ san gbese fu ẹni gbogbo: owo ode fu ẹniti owo ode iṣe ti rẹ̀; owo bode fu ẹniti owo bode iṣe ti rẹ̀; èru fu ẹniti èru iṣe ti rẹ̀; ọlá fu ẹniti ọlá iṣe ti rẹ̀.

Ihin-rere. Mat. 8. 23.

NIGBATI o sì bọ si ọkọ̀, awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ tẹ̀le e. Sì wò o, afẹfẹ nla dide ninu adagun tobẹ́ ti a fi bò ọkọ̀ mọlẹ ninu riru omi; ṣugbọn on sùn. Awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ tọ̀ ọ wá, nwọn jí i, nwọn nwipe, Oluwa, gbà

Digitized by Google

wa là, awa gbé. O sì wi fu wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi ṣe ojo bẽ, Ẹnyin onigbagbọ́ kekere? Nigbana li o dide, o sì ba afẹfẹ ati adagun wi; idakẹrọrọ sì de. Ṣugbọn ẹnu yà awọn ọkọnri na, nwọn wipe, Irú ọkọnri kili eyi, ti afẹfẹ ati omi adagun gbà ti rẹ gbọ́? Nigbati o sì de apa ekeji ni ilẹ ti awọn ara Gergesene, awọn ọkọnri meji eleṣu pade rẹ, nwọn nti inu ile ibojì jade wá, nwọn rorò gidigidi tobẽ ti ẹnikan kò le kọja li ọna ibẹ. Sì wò o, nwọn kigbe soke wipe, Kini si wa ati si iwọ, Jesu, iwọ Ọmmọ Ọlọrun? iwọ wá lati da wa loro kì o to di akokò na? Agbo ọpọ ẹlẹdẹ ti njẹ mbẹ li ọna jijìn si wọn. Awọn èṣu na si bẹ ẹ, wipe, Bi iwọ ba lé wa jade, jẹ ki awa ki o lọ sinu agbo ẹlẹdẹ yi. O sì wi fu wọn pe, Ẹ ma lọ. Nigbati nwọn sì jade, nwọn lọ sinu agbo ẹlẹdẹ na; sì wò o, li agbara ni gbogbo agbo ẹlẹdẹ na sure lọ li ogedengbe sinu adagun, nwọn sì ṣegbé ninu omi. Awọn ẹniti nṣọ wọn sì sá, nwọn sì mu ọna wọn pọn lọ si ilu-nla, nwọn ròhin ohun gbogbo, ati ohun ti a ṣe fu awọn eleṣu. Sì wò o, gbogbo ara ilunla na sì jade wá ipade Jesu; nigbati nwọn sì ri i, nwọn bẹ ẹ, ki o le lọ kuro li àgbegbe wọn.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKARUN LẸHIN IFIHÀN.

Adura.

OLUWA, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ lati pa Ijọ awọn enia rẹ ati awọn ara ile rẹ mọ nigbagbogbo ni ìsin rẹ otitọ; ki a ma dãbobo awọn ti nfi ara le kìki ireti ore-ọfẹ rẹ ọrun siwaju nipa agbara ula rẹ; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. Kol. 3. 12.

NITORINA, bi ayanfẹ Ọlọrun, ẹni mimọ́ ati olufẹ, ẹ gbé iyọnu ãnu wọ̀, iṣeun, irẹlẹ ọkkàn, inu tutù, ipamọra; ẹ ma fi sũru gbà ọmmọnikeji nyin, ki ẹ sì ma darijì ọmmọnikeji nyin, bi ẹnikẹni ba ni ìja si ẹnikan: bi Kristi ti darijì nyin, gẹgẹ bẹ̃ni ki ẹnyin ki o ma ṣe pẹlu. Ati bori gbogbo nkan wọnyi, ẹ gbé ifẹni wọ̀, ti iṣe àmure fu ìwa pipé. Ẹ sì jẹ ki alafia Ọlọrun ki o ma ṣe olori li àiya nyin, sinu eyiti a fi npè nyin pẹlu ninu ara kan; ki ẹnyin ki o sì ma dupẹ. Ẹ jẹ ki ọ̀rọ Kristi ki o ma gbé inu nyin li ọ̀pọlọpọ nipa ọgbọ́n gbogbo; ki ẹ ma kọ́, ki ẹ sì ma gbà ara nyin niyanju ninu orin mimọ́ (Psalmu), ati ninu orin iyìn, ati orin nipa ti ẹmmí, ẹ ma fi oreọfẹ kọnrin li àiya nyin si Oluwa. Ohunkohun ti ẹnyin ba sì nṣe li ọ̀rọ tabi ni iṣe, ẹ ma ṣe gbogbo wọn li oruko Jesu Oluwa, ẹ ma fi ọpẹ́ fu Ọlọrun ati Babba nipasẹ rẹ̀.

Ihin-rere. Mat. 13. 24.

IJỌBBA ọrun dabi ọkọnri ti o fọn irugbin rere si oko rẹ̀: ṣugbọn nigbati awọn enia sùn, ọtá rẹ̀ wá, o fọn èpo buburu sinu alikama, o sì ba ti rẹ̀ lọ. Ṣugbọn nigbati èhu rẹ̀ sọ jade, ti o sì so eso, nigbana li èpo buburu fi ara hàn pẹlu. Bẹ̃li awọn ọmmọ ọdọ bãle na tọ̀ ọ wá, nwọn wi fu u pe, Oluwa, irugbin rere ki iwọ fọn sinu oko rẹ? nibo li o ha ti li èpo buburu? O sì wi fu wọn pe, Ọtá li o ṣe eyi. Awọn ọmmọ ọdọ rẹ̀ sì bi i pe, Iwọ o ha jẹ ki awa ki o lọ tú wọn kuro? O sì wipe, Ndao, nigbati ẹnyin ba ntú èpo buburu kuro, ki ẹnyin ki o máṣe tú alikama pẹlu. Ẹ jẹ ki awọn mejeji ki o dàgba pọ̀ titi di igba

Digitized by Google

ikorè: li akokò ikorè emi o wi fu awọn alakore pe, Ẹ tète kó èpo buburu jọ, ẹ di wọn ni ití lati fi iná run wọn; ṣugbọn ẹ kó alikama sinu abà mi.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸFA LẸHIN IFIHÀN.

Adura.

ỌLỌRUN, ẹniti Ọmmọ rẹ olubukún di hihàn, ki o le pa iṣẹ èṣu run, ki o sì le sọ wa di ọmmọ Ọlọrun, ati ajogun lye alnipẹkun; Fifu wa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, bi awa ti n-ni ireti yi, ki awa ki o le wẹ ara wa nù mọ, ani bi on ti mọ; pe nigbati on yio sì tún fi ara hàn, ti on ti agbara ati ogo nla, ki a sì le sọ wa dabi rẹ ni ijọbba rẹ lai ti o sì li ogo; nibi pẹlu rẹ, Babba, ati pẹlu rẹ, Ẹmmí Mimọ, ti o gbé wà, ti o sì njọbba, lai Ọlọrun kan, aiyé alnipẹkun. *Amin.*

Epistéli. 1 Joh. 3. 1.

KIYESI i, irú ifẹ ti Babba fi bù wa, pe ki a le ma pè wa li ọmmọ Ọlọrun: nitorina aiye kò mọ wa, nitoriti kò mọ ọ. Olufẹ, njẹ nisisiyi ọmmọ Ọlọrun li awa iṣe, kò sì ti fihàn bi awa o ti jasi: ṣugbọn awa mọ pe, nigbati on yio farahàn, awa o dabi rẹ; nitoriti awa o ri i bi on ti ri. Ati olukuluku ẹniti a ba ni ireti yi ninu rẹ, a wẹ ara rẹ mọ, gẹgẹ bi on sì ti mọ. Ẹnikẹni ti o dẹṣẹ o ru ofin pẹlu: nitori ẹṣẹ ni riru ofin. Ẹnyin sì mọ pe, on farahàn lati mu ẹṣẹ wa kuro; ati lara rẹ ẹṣẹ kò si. Ẹnikẹni ti o ba ngbé inu rẹ kò ṣẹ: ẹnikẹni ti o ba ṣẹ kò ri i, bẹ̀ni ko mọ ọ. Ẹnyin ọmmọde, ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni ki o tàn nyin: ẹniti o ba nṣe ododo, o jasi olododo,

Digitized by Google

gẹgẹ bi on ti iṣe olododo. Ẹnikẹni ti o ba dẹṣẹ ti èṣu ni; nitoriti èṣu ti ṣẹ lati igba àtetekọṣe. Nitori idi eyi li Ọmmọ Ọlọrun farahàn, nitoripe ki o le pa iṣẹ ti èṣu run.

Ihin-rere. Mat. 24. 23.

NITORINA bi ẹnikan ba wi fu nyin pe, Wò o, Kristi mbẹ nihinyi, tabi lọhún; ẹ máṣe gbà a gbọ́. Nitori awọn eke Kristi, ati eke woli ni yio dide, nwọn yio sì fi àmi ati ohun iyanu nla hàn; tobẹ̃ bi o le ṣe ti nwọn iba fi tàn awọn ayanfẹ papa. Kiyesi i, mo wi fu nyin tẹlẹ. Nitorina bi nwọn ba wi fu nyin pe, Sawò o, o wà li aganjù; ẹ má lọ sibẹ: wò o, o wà ni ìkọkọ yará; ẹ máṣe gbà a gbọ́. Nitoripe gẹgẹ bi manamana ti ìha ìla õrùn kọ sãn, ti si mọlẹ ni ìha ìwọ õrùn; gẹgẹ bẽni wíwa ti Ọmmọ ọkọnri yio ri pẹlu. Nitori ibikibi ti okú ba sá gbé wà, ibẹ li awọn idì kojọ pọ̀ si. Lojukan na lẹhin ipọnju ti ọjọ wọn-ni li õrùn yio ṣòkun, oṣupá kì yio sì fi imọlẹ rẹ̀ hàn, awọn irawọ yio ti oju ọrun já silẹ, agbara ti oju ọrun li a o sì mì-titì: nigbana li àmi ti Ọmmọ ọkọnri yio sì fi ara hàn li ọrun: nigbana ni gbogbo orilẹ ède li aiye yio kãnu, nwọn o sì ri Ọmmọ ọkọnri tì yio ma ti oju ọrun bọ̀ ti on ti agbara ati ogo nla. Yio sì rán awọn angeli rẹ̀ ti awọn ti ohùn ìpe nla, nwọn yio sì kó gbogbo awọn ayanfẹ rẹ̀ lati ori igọn mẹrẹrin aiye jọ, lati ikangun ọrun ekini lọ de ekeji.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸTA ṢAJỤ LENTI.

Adura.

OLUWA, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, li oju-rere gbọ́ adura awọn enia rẹ; ki awa, ti a nṣẹ̀ niṣẹ

Digitized by Google

nitori ẹṣẹ wa bi o ti yẹ, ki a le fi ãnu gbà wa silẹ nipa ore rẹ, nitori ogo Orukọ rẹ; nitori Jesu Kristi Olugbala wa, ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu rẹ ati Ẹmmí Mimọ́, lai Ọlọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Epistéli. 1 Kor. 9. 24.

ENYIN kò mọ pe gbogbo awọn ti o sáre ije kan ni isáre, ṣugbọn ẹnikan ni igbà ère na? Ẹ sáre bẽ, ki ẹnyin ki o le ri gbà. Ati olukuluku ẹniti njijà ati bori a ma wà li alrekọja ninu ohun gbogbo. Ṣugbọn nwọn nṣe e lati gbà adé kan ti idibajẹ; ṣugbọn awa eyi ti kì idibajẹ. Nitorina bẽni emi nsáre, kì iṣe bi ẹnipe ninu òkunkun; bẽni emi njà, kì iṣe bi ẹnikan ti mbẹ afẹfẹ: ṣugbọn emi nrẹ ara mi silẹ, mo sì nmu u wá sabbẹ itẹriba: lẹhin igbati mo ti wasu fu awọn ẹlomiran tan, nitori ohunkohun, ki emi tikara mi ki o máṣe di ẹniti a o tanù.

Ihin-rere. Mat. 20. 1.

IJỌBBA ọrun sá dabi ọkọnri kan ti ṣe bãle ile, ti o jade ni kutukutu owurọ lọ lati pè awọn alagbaṣe sinu ọgba ajara rẹ. Nigbati o sì ba awọn alagbaṣe pin-nu rẹ si owo idẹ kọkan li ọjọ, o rán wọn lọ sinu ọgba ajara rẹ. O sì jade lakokò wakati ẹkẹta ọjọ, o ri awọn alalrisẹ omiran, nwọn duro nibi ọjà, o sì wi fu wọn pe; Ẹ lọ si ọgba ajara pẹlu, ohunkohun ti o ba tọ́ emi o fifu nyin. Nwọn sì mu ọna wọn pọn lọ sibẹ. O tún jade lọ lakokò wakati ẹkẹfa ati ẹkẹsan ọjọ, o sì ṣe bẽ. O sì jade lọ lakokò wakati ẹkọkanla ọjọ, o ri awọn alalrisẹ omiran ti o duro, o sì wi fu wọn pe, Ẽṣe ti ẹnyin fi duro lati onimoni li alrisẹ? Nwọn wi fu u pe, Nitoriti kò si ẹni ti o fu

Digitized by Google

wa li agbaṣe; O wi fu wọn pe, Ẹ lọ pẹlu ẹnu ọgba ajara; eyi ti o ba tọ li ẹnyin o ri gbà. Nigbati o di oju alẹ, oluwa ọgba ajara wi fu iriju rẹ pe, Pè awọn alagbaṣe ni, ki o sì fi owo agbaṣe wọn fu wọn, bẹrẹ lati ẹni ikẹhin lọ si ti iṣaju. Nigbati awọn ti a pè lakokò wakati ẹkọkanla ọjọ de, gbogbo wọn gbà owo idẹ kọkan. Ṣugbọn nigbati awọn ti o ti ṣaju de, nwọn ṣebi awọn o gbà jù bẹ̃ lọ; olukuluku wọn sì gbà owo idẹ kọkan. Nigbati nwọn gbà a tan, nwọn nkù si bãle rere na, wipe, Awọn ara ikẹhin ṣiṣẹ kìki wakati kan ọjọ, iwọ sì mu wọn bá wa ṣe ọgbọgba, awa ti o ti nrù ẹrù, ati ti a sì gbà oru ọjọ. O sì da ọkan ninu wọn lohùn pe, Ọrẹ, emi kò ṣìṣe si ọ: iwọ kì o ba mi pinnu rẹ si owo idẹ kan li ọjọ? Gbà eyi ti ṣe ti rẹ, ki o sì ma ba ti rẹ lọ: Emi o sì fifu ikẹhin yi, gẹgẹ bi mo ti fifu ọ. Kò tọ ki emi ki o fi nkan ti ṣe ti emi ṣe bi o ti wù mi? Oju rẹ korò nitoriti emi ṣe ẹni rere? Bẽli awọn ẹni ikẹhin yio di ti iwaju, awọn ẹni iwaju yio sì di ti ikẹhin: nitori ọpọlọpọ li a pè, ṣugbọn diẹ li a o ri yàn.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKEJI ṢAJU LENTI.

Adura.

OLỌRUN Oluwa, iwọ ti o ri pe awa kò gbẹkẹle ohun-kohun kan ti awa nṣe; Fi ãnu fifu wa nipa agbara rẹ, ki a le ma dãbobo wa si alàni ati ipọnju gbogbo; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 2 Kor. 11. 19.

ẸNYIN fi inu-didùn gbà awọn aṣiwère nigbati ẹnyin tikara nyin jẹ ọlọgbọn

Digitized by Google

Nitori ẹnyin gbà pe, bi ẹnikan ba sọ nyin di ondè, bi ẹnikan ba gbé nyin mì, bi ẹnikan ba gbà lọwó nyin, bi ẹnikan ba gbé ara rẹ ga, bi ẹnikan ba gbá nyin loju. Emi nsọ gẹgẹ nipa ti ẹgan, bi ẹnipe awa ti jẹ alaìlera. Ṣugbọn ninu ohunkohun ti ẹnikan ni igboiya, (emi nsọ bi aṣiwère,) emi ni igboiya pẹlu. Iṣe Heberu ni nwọn bi? bẽli emi. Iṣe ara Israeli ni nwọn bi? bẽli emi. Iṣe irú ọmmọ Abrahamu ni nwọn bi? bẽli emi. Iṣe alufa Kristi ni nwọn bi? (emi nsọ bi aṣiwère) mo ta wọn yọ; niti iṣẹ lọpọlọpọ, niti paṣan mo rekọja, niti tubu nigbakugba, niti ikú nigba-gbogbo. Nigba marun ni mo gbà paṣan mọkandilogoji nigba kọkan lọwọ́ awọn Ju. Nigba mẹta li a fi ọgọ lù mi, nigba kan li a sọ mi li okuta, nigba mẹta li ọkọ rì mi, lọsán ati loru ni mo ti nwà larin ibú; ni ìrin àjo nigbakugba, ninu ewu omi, ninu ewu awọn ọlọṣa, ninu ewu awọn ara ilu mi, ninu ewu awọn keferi, ninu ewu ni ilu nla, ninu ewu li aginjù, ninu ewu loju okun, ninu ewu larin awọn eke arakọnri; ninu ãrẹ ati irora, ninu iṣọra nigbakugba, ninu ebi ati ọrùngbẹ, ninu àwẹ nigbakugba, ninu otutù ati ìhoho. Pẹlu nkan wọn-ni ti o wà lode, eyi ti nwọjọ tì mi li ojojumọ́, aniyan ti gbogbo ijọ awọn enia Ọlọrun. Tani iṣe alaìlera, ti emi kò ṣe alaìlera? tabi tali amuṣẹ, ti ara mi kò gbina? Bi emi kò le ṣaìma ṣogo, emi yio kuku ma ṣogo nipa awọn nkan ti iṣe ti allera mi. Ọlọrun ati Babba Jesu Kristi Oluwa wa, ẹniti iṣe olubukún julọ lailai, mọ́ pe emi kò ṣeke.

Ihin-rere. Luku 8. 4.

NIGBATI ọpọ awọn enia pejọ pọ́, lati ilu nla gbogbo tọ ọ wá, o fi owe sọrọ fu wọn

Digitized by Google

pe: Afọnrugbin kan jade lọ lati fọn irugbin rẹ̀: bi o sì ti nfọnrugbin, diẹ bọ si ẹba ọna; a sì tẹ̀ ẹ mọlẹ, awọn ẹiyẹ oju ọrun sì ṣà a jẹ. Omiran sì bọ sori apatta; bi o sì ti hù jade, o gbẹ nitoriti kò ni irinlẹ omi. Omiran sì bọ sinu ẹgún; ẹgún sì ba a rú soke, o sì fun ọ pa. Omiran sì bọ si ilẹ rere, o sì rú soke, o sì so eso ọrọrun. Nigbati o sì wi nkan wọnyi tan, o nahùn wipe, Ẹniti o ba li etí lati fi gbọ́, ki o gbọ́. Awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ sì bi i lẽre, wipe, Kili a le mọ̀ owe yi si? Ó sì wi fu wọn pe, Ẹnyin li a fifu lati mọ̀ ọ̀ro ijinlẹ ti ijọba Ọlọrun: ṣugbọn fu ẹlomiran li owe; ti nwọn nri ki nwọn ki o má le ri, ti nwọn sì ngbọ́ ki o má le yé wọn. Njẹ owe na li eyi: Irugbin li ọ̀rọ Ọlọrun. Awọn ti ẹba ọna li awọn ti o igbọ́; nigbana li èṣu wá, o sì mu ọ̀rọ na kuro li okkàn wọn, ki nwọn ki o má ba gbagbọ́, ki a ma ṣe gbà wọn là. Awọn ti ori apatta li awọn, nigbati nwọn gbọ́, nwọn fi ayọ̀ gbà ọ̀rọ na; nwọn kò sì ni gbòngbo, ti nwọn gbagbọ́ diẹ si, nigbati o sì di igba idanwò, nwọn a sì pada sẹhin. Awọn ti o bọ sinu ẹgún li awọn, nigbati nwọn gbọ́ tan, nwọn lọ, nwọn a sì fi itọju ati ọrọ̀ ati irọra aiye fun ọ pa, nwọn kò sì ti le so eso asogbo. Ṣugbọn ti ilẹ rere li awọn, ti nwọn gbọ́ ọ̀rọ na si ọkkàn otitọ ati rere, nwọn pa a mọ́, nwọn sì fi sũru so eso.

ỌJỌ ỌLỌRUN TI O ṢAJU LENTI.

Adura.

OLUWA, iwọ ti o ti kọ́ wa pe, gbogbo iṣe wa lalni ifẹni kò yẹ nkan; Rán Ẹmmí Mimọ́ rẹ, ki o sì tú ẹbun ifẹni daradara julọ

Digitized by Google

ni si wa li àiya, ọjá eyi ọjá alafia ati ti gbogbo ìwa-ọrun, lalni eyi na, ẹnikẹni ti mbẹ li ãye, a kà a si okú niwaju rẹ: Fi eyi funi nitori ti Ọmmọ rẹ nikanṣoṣo Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Kor. 13. 1.

BI mo tilẹ nfi ède enia ati ti awọn angeli sọrọ, ti emi kò sì ni ifẹni, emi dabi idẹ ti ndún, tabi bi ohun èlo orin (kimbali) olohùn gõro. Ani bi mo tilẹ li ẹbun isọtẹlẹ, ti mo sì moye gbogbo ọrọ ijinlẹ, ati gbogbo ìmọ; ati bi mo tilẹ ni gbogbo igbagbọ, tobẹ ti mo le ṣí awọn òke nla nipò, ti emi kò sì ni ifẹni, asan ni mi. Ani bi mo tilẹ fi gbogbo ẹrù mi jìn lati fi bọ awọn talakà, ati bi mo sì fi ara mi funi ni sisọn ninu iná, ti emi kò sì ni ifẹni, kò ṣe ère kan fu mi. Nitori ifẹni a ma jìya pẹ titi, o sì ṣeun; ifẹni kì iṣe ilara; ifẹni kì igbé ara rẹ ga, on kì sì ifẹ soke, on kì ifi ara rẹ ṣe ohun ti kò tọ, bẹ̃ni kì iwá eyi ti ṣe ti ara rẹ, a kì imu u binu kankan, bẹ̃ni kì igbiro ohun buburu; ifẹni kì iyọ sí ìwa buburu, ṣugbọn a ma yọ ninu otitọ; on a ma gbiyanju ohun gbogbo, a sì ma gbà ohun gbogbo gbọ, a ma reti ohun gbogbo, a sì ma fi àiya rán ohun gbogbo. Ifẹni kì iyẹ titi lai: ṣugbọn bi o ba ṣepe awọn isọtẹlẹ li o wà, nwọn o sì dopin; bi o ba ṣepe ẹbun ahọn ni, nwọn o sì dakẹ; bi o ba ṣepe ìmọ ni, on yio sì di asan. Nitoripe awa ni ìmọ li apakan, awa sì nsọtẹlẹ li apakan. Ṣugbọn nigbati eyi ti o pé ba de, eyi ti iṣe ti apakan yio ti ọna kuro. Nigbati mo wà li ewe, emi a ma sọrọ bi ewe, emi a ma moye bi ewe, emi a sì ma rò bi ewe: ṣugbọn nigbati mo di ọkọnri tan, mo fi ìwa ewe silẹ. Nitoripe awa nriran baibai ninu awojiji; ṣug-

Digitized by Google

bọn nigbana ni ifojukoju: nisisiyi mo mọ̀ li apakan; ṣugbọn nigbana li emi o mọ̀, gẹgẹ bi mo sì ti di mimọ̀ pẹlu. Ati nisisiyi igbagbọ́, ireti, ati ifẹni mbẹ, awọn mẹta; ṣugbọn eyiti o tobi jù wọnyi lọ ni ifẹni.

Ihin-rere. Luku 18. 31.

NIGBANA li o pè awọn mejejila sọdọ rẹ̀, o sì wi fu wọn pe, Sawò o, awa ngòke lọ si Jerusalemu, a o sì mu ohun gbogbo ṣẹ, ti a ti kọ lati ọwọ́ awọn woli wá, nitori Ọmmọ ọkọnri. Nitori a o fi i le awọn Keferi lọwọ́, a o fi i ṣe ẹlẹyà, a o sì fi i ṣe ẹsin, a o sì tutọ́ si i lara: nwọn yio sì nà a, nwọn yio sì pa a: ni ijọ ẹkẹta yio sì tún dide. Ọkan ninu nkan wọnyi kò sì yé wọn: ọ̀rọ yi sì pamọ́ fu wọn, bẹ̃ni nwọn kò sì mọ̀ ohun ti a wi. O sì di igbati o ṣe, bi on ti sumọ́ Jeriko, afọju kan joko lẹba ọ̀na o nṣagbe: nigbati o gbọ́ ti ọwọ́ enia nkọja lọ, o bère pe, kili a le mọ̀ eyi si. Nwọn sì wi fu u pe, Jesu ti Nasareti li o nkọja lọ. O sì kigbe pe, Jesu, iwọ Ọmmọ Dafidi, ṣãnu fu mi. Awọn ti nlọ niwaju ba a wi pe, ki o pa ẹnu rẹ̀ mọ́: ṣugbọn on sì kigbe si i kikun pe, Iwọ Ọmmọ Dafidi, ṣãnu fu mi. Jesu sì dẹṣẹ duro, o ni, ki a mu u tọ̀ on wá: nigbati o sì sumọ́ ọ, o bi i, wipe, Kini iwọ nfẹ ti emi iba ṣe fu ọ? O sì wipe, Oluwa, ki emi ki o le riran. Jesu sì wi fu u pe, Riran: igbagbọ́ rẹ gbà ọ là. Lojukan na o sì riran, o sì ntọ̀ ọ lẹhin lọ, o nyìn Ọlọrun logo: ati gbogbo awọn enia nigbati nwọn ri i, nwọn fi iyìn fu Ọlọrun.

Digitized by Google

ỌJỌ EKINI LENTI, TI A NPÈ NI ỌJỌ WEDNESDAY ÊRU.

Adura.

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, iwọ ẹniti kò korira ohun-kohun ti o da, ati ti iwọ sì ndari ẹ̀ṣẹ̀ jì gbogbo awọn ti o ronupiwada; Da, ki iwọ ki o sì ṣe àiya titun ati irora ọkkàn ninù wa, bi awa ti npohun-rere ẹkún ẹ̀ṣẹ̀ wa bi o ti yẹ, ati bi awa sì ti njẹwọ òṣi wa, ki awa ki o le ri imukuro ati idariji ti o pé gbà lọwọ́ rẹ, Ọlọrun ãnu gbogbo; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Epistéli. Joeli 2. 12.

OLUWA wipe, ani Ẹ yipada si mi ti ẹnyin ti àiya nyin gbogbo, ati pẹlu àwẹ, ati pẹlu ẹkun, ati pẹlu ikanu, ki ẹ sì fà àiya nyin ya, kì isì iṣe aṣọ nyin ki ẹ sì yipada si Oluwa Ọlọrun nyin: nitoriti o pọ̀ li ore ọfẹ ati fu anu, kì ibinu kankan, o sì ṣe olore pupọ̀, o sì ronupiwada ati ṣe ohun buburu. Ta li o mọ̀ bi on o yipada ti yio sì ronupiwada, ti yio sì fi ibukún silẹ lẹhin rẹ̀, ani ọrẹ ẹbọ ohun jijẹ, ati ọrẹ ẹbọ ohun mimu fu Oluwa Ọlọrun wa? Ẹfun ìpe ni Sion ẹ ya ìgba àwẹ ṣọtọ, e pe apejọ ti oni ironu, ẹ pe awọn enia jọ, ẹ ya ijọ enia ṣọtọ, ẹ pe awọn àgbagba jọ, ẹ ko awọn ọmmọde jọ, ati awọn ọmmọ ọmu; ki ọkkọ iyawo ki o jade lati iyara rẹ̀ wá, ati iyawo lati iyẹwu rẹ̀, ki awọn alufa iranṣẹ Oluwa, ki o ma sọkun lagbedemeji iloro ati pepele ni ki nwọn ki o sì ma wipe, Oluwa da awọn enia rẹ si ki o má sì ṣe fi awọn enia rẹ fu ẹgan, ki awọn kefẹri ki o ma ṣe jẹ olori nwọn. Nitoriti ki ni wọn yio ṣe ma wi ninu awọn enia pe, Nibo li Ọlọrun wọn wa?

Digitized by Google

Ihin-rere. Mat. 6. 16.

NIGBATI ẹnyin ba ngbàwẹ, ẹ máṣe dabi awọn agabagebe ni oloju fifaro; nwọn a ba oju jẹ, ki nwọn ki o ba le fi ara hàn fu awọn enia pe nwọn ngbàwẹ. Lõtọ ni mo wi fu nyin, Nwọn ti gbà ère wọn na. Ṣugbọn iwọ, nigbati iwọ ba ngbàwẹ, fi oróro kùn ori rẹ, ki o sì bọju rẹ; ki iwọ ki o máse fi ara hàn fu awọn enia pe iwọ ngbàwẹ, bikoṣe fu Babba rẹ ti o mbẹ ni ìkọkọ; Babba rẹ ti o sì riran ni ìkọkọ yio san a fu ọ ni gbangba. Ẹ máṣe tò iṣura jọ fu ara nyin li aiye, nibiti kòkoro ati ipara ṣe ba a jẹ, ati nibiti awọn olè runlẹ ti nwọn sì jale. Ṣugbọn ẹ kó iṣura jọ fu ara nyin li ọrun, nibiti kòkoro ati ipara kò le ba a jẹ, ati nibiti awọn olè kò le runlẹ ki o jale. Nitori nibiti iṣura nyin gbé wà, nibẹ̀ li okkàn nyin yio gbé wà pẹlu.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKINI NI LENTI.

Adura.

OLUWA, nitori wa iwọ ti o gbàwẹ li ogoji ọsán ati ogoji oru; Fi ore-ọfẹ fu wa ki awa ki o le ma ṣe irú irọnu bẽ, ni pe ti ẹran ara wa ntẹriba fu Ẹmmí, lai ki awa ki o ma gbà igbedide rẹ gbọ́ ninu ododo, ati nitõtọ ìwa-mimọ́ fu ọllá ati ogo rẹ, ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu Babba ati Ẹmmí Mimọ́, Ọlọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Episteli. 2 Kor. 6. 1.

NITORINA awa, bi alabaṣe pọ́ pẹlu rẹ̀, awa mbẹ̀ nyin pẹlu ki ẹnyin ki o máṣe gbà ore-ọfẹ Ọlọrun lasan. (Nitoriti o wipe, emi

Digitized by Google

ti gbohùn rẹ li akokò kan ti itẹwọgbà, ati li ọjọ igbala ni mo sì ti ràn ọ lọwọ́: kiyesi i, nisisiyi ni akokò itẹwọgbà; kiyesi i, nisisiyi ni ọjọ igbala.) Awa kò sì fi ohun ikọsẹ kan ṣe ẹnikẹni, ki iṣẹ alufa ki o máṣe di isọrọ buburu si: ṣugbọn li ohun gbogbo awa nyìn ara wa bi awọn alufa Olọrun, ninu ọpọlọpọ sũru, ninu ipọnju, ninu ainí, ninu wahalà pipọ́, nipa ìna, ninu tubu, nipa ìti soke ti sodo pipọ́, nipa iṣẹ, nipa iṣọra, nipa igbawẹ pipò; nipa ìwa mimọ́, nipa ìmọ, nipa ipamọra, nipa iṣeun, nipa Ẹmmí Mimọ́, nipa ifẹ alṣẹtan, nipa ọrọ otitọ, nipa agbara Olọrun, nipa ihamọra ododo li apa ọtún ati li apa òsin, nipa ọllá ati ègan, nipa ihin buburu ati ihin rere: bi ẹlẹtan, ṣugbọn a sì jasi olõtọ; bi ẹniti a kò mọ́, ṣugbọn a sì ti di mimọ́, dajudaju; bi ẹniti nkú lọ, sì kiyesi i, awa wà lãye; bi ẹniti a n-nà, kì sì iṣe ti pipa; bi ẹniti o kún fu ibinujẹ, ṣugbọn awa nyọ́ nigbagbogbo; bi talakà, ṣugbọn awa nsọ ọpọlọpọ di ọlọrọ̀; bi ẹniti kò ni nkan, ṣugbọn awa sì nlò ohun gbogbo.

Ihin-rere. Mat. 4. 1.

NIGBANA li a dari Jesu si ijù lati ọwọ́ Ẹmmí lati dan a wò lọwọ́ èṣu. Nigbati o gbàwẹ li ogoji ọsán ati ogoji oru, lẹhin igbana ni ebi npa a. Nigbati oludanwò de ọdọ rẹ̀, o ni, Bi iwọ iba ṣe Ọmmọ Olọrun, wi fu awọn okuta wọnyi ki nwọn di akara. Ṣugbọn o dahùn wipe, A ti kọwe rẹ pe, Enia kò wà nipa akara nikan, bikoṣepe nipa gbogbo ọrọ ti o ti ẹnu Olọrun jade wá. Nigbana li èṣu gbé e lọ soke si ilu mimọ́ ni, o gbé e le ṣonṣo oke ti ile Olọrun, o sì wi fu u pe, Bi

Digitized by Google

iwọ iba ṣe Ọmmọ Ọlọrun, bẹ́ silẹ fu ara rẹ; a sá ti kọwe rẹ̀ pe, Yio kìlọ fu awọn angeli rẹ̀ nitori rẹ, li ọwọ́ wọn ni nwọn o sì gbé ọ soke, ki iwọ ki o má ba fi ẹsẹ rẹ ṣan okuta. Jesu sì wi fu u pe, A sì tún kọ ọ pe, Iwọ kò gbọdọ dan Oluwa Ọlọrun rẹ wò. Èṣu gbé e lọ si ori òke giga-giga ẹ̀wẹ, o sì fi gbogbo ilẹ ọbba aiye ati gbogbo ogo wọn hàn a; o sì wi fu u pe, Gbogbo nkan wọnyi li emi yio fifu ọ, bi iwọ ba wolẹ, ti iwọ foribalẹ fu mi. Nigbana ni Jesu wi fu u pe, Pada kuro lẹhin mi, Satan: nitoriti a kọwe rẹ̀ pe, Oluwa Ọlọrun rẹ ni ki iwọ ki o foribalẹ fu, on nikanṣoṣo ni ki iwọ ma sìn. Nigbana li èṣu fi i silẹ lọ, sì kiyesi i, awọn angeli tọ ọ wá, nwọn sì nṣe iranṣẹ fu u.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKEJI NI LENTI.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o ri pe awa kò li agbara kan fu ara wa lati ràn ara wa lọwọ́; Pa wa mọ́ ati lode li ara wa, ati ninu li ọkkàn wa; ki a le dãbobo wa kuro ninu ipọnju gbogbo ti o le ṣe biba ara, ati kuro ninu ironu buburu gbogbo, ti o le kọlù ti o sì le ṣẹ́ ọkkàn li ẹ̀ṣẹ́; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Tes. 4. 1.

AWA mbẹ̀ nyin, arakọnri, awa sì ngbà nyin niyanju nipa ti Jesu Oluwa, pe bi ẹnyin ti tẹwọgbà lọwọ́ wa bi ẹnyin iba ti ma rìn ti ẹnyin iba sì ma wù Ọlọrun, gẹgẹ bẹ̃ni ki ẹnyin ki o kuku ma pọ̀ si i gidigidi lọpọlọpọ. Nitori ẹnyin mọ́ irú ofin ti a ti fifu nyin nipa

Digitized by Google

Jesu Oluwa ni. Nitori eyi ni ifé Olorun, ani iwa mimó nyin, pe ki enyin ki o takéte si àgbere: ki olukuluku nyin ki o le mò bi on iba ti ma lò èlo rè ni iwa mimó ati ni ti ollá; kì ise ni sise ifekufe, gegè bi awon Keferi ti kò mò Olorun: ki enikeni ki o máse rekoja, ki o má sì se ré arakonri rè je li ohunkohun: nitoripe Oluwa ni ise olugbesan gbogbo irú enia bè, gegè bi awa sì ti so fu nyin nisaju, ti a sì jèri pelu. Nitoripe Olorun kò pè wa si iwa èri, bikose si iwa mimó. Nitorina enikeni ti o ba nkegan, kò kegan enia, bikose Olorun, eniti o sì ti fi Emmí Mimó rè fu wa pelu.

Ihin-rere. Mat. 15. 21.

NIGBANA ni Jesu ti ibè lo kuro, o sì lo si àgbegbe Tire on Sidon. Sá wò o, obiri kan ara Kanãn o ti ekùn na wá, o sì kigbe pè e, wipe, Oluwa, iwo ommo Dafidi sãnu fu mi; ommobiri mi li èsu nfi irora pupò daloro gidigidi. Sugbon kò sì da a lohùn kan. Awon ommo ehin rè wá, nwon bè e, wipe, Rán a lo kuro, nitoriti o nsokun tò wá lehin. Sugbon o dahùn wipe, A kò rán mi, bikose si awon agutan ti ile Israeli ti o nù. Nigbana li o wá, o sì teriba fu u, wipe, Oluwa, ràn mi lowó. Sugbon o dahùn, wipe, Kò tó ki a mu akara ti se ti awon ommo, ki a fi i fu ajá. O sì wipe, Otito ni, Oluwa; sugbon awon ajá a ma je erún ti o ti ori tabeli oluwa won bo silè. Nigbana ni Jesu dahùn o sì wi fu u pe, Obiri yi, igbagbó nla ni ti re: ki o sì ri fu o gegè bi iwo ti nfe. A sì mu ommobiri rè lara da sasa ni wakati kan na.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸTA NI LENTI.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ ṣijuwò ifẹ́ atọkkanwa ti awọn iranṣẹ rẹ wọnyi oniręlẹ ọkkàn, ki o sì nà ọwọ́ ọtún ti Ọlá-nla rẹ jade, lati ṣe àbo wa si oju awọn ọtá wa gbogbo; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Efes. 5. 1.

NITORINA ẹ ma ṣe ọmmọ lẹhin Ọlọrun bi awọn ọmmọ ọwọn; ki ẹ sì ma rìn ninu ifẹ́, gẹgẹ bi Kristi pẹlu ti fẹ wa, ti o sì fi ara rẹ̀ fu wa bi ọrẹ ẹ̀bun ati ẹbọ fu Ọlọrun fu õrun didùn. Ṣugbọn àgbere, ati gbogbo ìwa ẽri, tabi ojukòkoro, ki a máṣe darukọ rẹ̀ larin nyin mọ́, bi awọn ẹniti o di enia mimọ́; iba ṣe ìwa ọ̀bọn, ati sisọ̀rọ aṣiwère, tabi iṣẹ̀fẹ, awọn ti kò tọ́: ṣugbọn ẹ kuku ma dupẹ. Nitori ẹnyin ti mọ̀ eyi pe, kò si panṣaga, tabi alaimọ́ enia, tabi olojukòkoro, ti iṣe olubọrisa, ti yio ni ini kan ni ijọbba Kristi ati ti Ọlọrun. Ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni fi ọ̀rọ asan tàn nyin jẹ: nitori nipasẹ nkan wọnyi ibinu Ọlọrun mbọ̀ wá sori awọn ọmmọ alaigbọran. Nitorina ẹ máṣe jẹ alajọpin pẹlu wọn. Nitori ẹnyin ti jẹ ọ̀kunkun lẽkan, ṣugbọn nisisiyi ẹnyin di imọlẹ nipa ti Oluwa: ẹ ma rìn gẹgẹ bi awọn ọmmọ imọlẹ: (nitori eso ti Ẹmmí wà niti iṣore gbogbo, ati ododo, ati otitọ;) on a ma wadi ohun ti iṣe itẹwọgbà fu Oluwa. Ki ẹ má sì ṣe ba àlleso iṣẹ ọ̀kunkun kẹgbẹ pọ̀, ṣugbọn ẹ kuku ma ba wọn wi. Nitoripe itiju tilẹ ni lati ma sọ̀rọ nkan wọn-ni ti nwọn nṣe nikọ̀kọ. Ṣugbọn ohun gbogbo ti a mba wi li a fihàn nipa imọlẹ: nitori ohunkohun ti o ba fi ara hàn ni iṣe imọlẹ. Nitorina li o ṣe wipe, Jí

Digitized by Google

iwọ ẹniti o sùn, ki o sì jinde kuro ninu okú, Kristi yio sì fu ọ ni imọlẹ.

Ihin-rere. Luku 11. 14.

JESU sì nlé èṣu kan jade, ti o sì yadi. O sì ṣe, nigbati èṣu na jade, odi nfọhun; ẹnu sì yà awọn enia. Ṣugbọn awọn ẹlomiran ninu wọn wipe, Ọllá ti Beelsebubu olori ti awọn èṣu li o fi nlé awọn èṣu jade. Ati awọn ẹlomiran, ndan a wò, nwọn nfẹ ki o fi àmi kan hàn fu wọn lati ọrun wá. Ṣugbọn o nmọ̀ ìro inu wọn, o wi fu wọn pe, Gbogbo ijọbba ti o yà ara rẹ̀ ni ipa, a sọ ọ di ahoro; ile ti o sì yà ara rẹ̀ ni ipa a wó. Bi Satan sì yàpa si ara rẹ̀, ijọbba rẹ̀ yio ha ṣe duro? nitoriti ẹnyin wipe, emi nfi ọllá ti Beelsebubu lé awọn èṣu jade. Bi o ba sì ṣepe ọllá ti Beelsebubu li emi fi nlé awọn èṣu jade, ọllá ti tali awọn ọmmọ nyin fi nlé wọn jade? nitorina ni nwọn o fi ma ṣe onidajọ nyin. Ṣugbọn bi o ba ṣepe ika Ọlọrun li emi fi nlé awọn èṣu jade, kò si aniani, ijọbba Ọlọrun de ba nyin. Nigbati ọkọnri alagbara ti o hamọra ba nṣọ afin rẹ̀, ẹrù rẹ̀ a wà li alafia: ṣugbọn nigbati ọkọnri alagbara jù u ba kọlù u, ti o ṣẹgun rẹ̀, o gbà gbogbo ihamọra rẹ̀ ti o gbẹkẹle lọwọ́ rẹ̀, a sì pín gbogbo ikogun rẹ̀. Ẹniti kò ba bá mi gbé, o nṣe òdi si mi: ẹniti kò ba sì bá mi kopọ̀, a fọn ká kiri. Nigbati èṣu kan ba jade kuro lara enia, a ma rìn kiri ni ibi gbigbẹ, a ma wá ibi isimi; nigbati kò ba sì ri, o ni, Emi o pada lọ si ile mi nibiti mo gbé ti jade lọ. Nigbati o sì de, o bá a, a sì gbá a, a sì ṣe e li ọṣọ́. Nigbana li o lọ, o sì mu èṣu meje omiran ti o buru jù on tikararẹ̀ lọ; nwọn wọle, nwọn sì joko nibẹ̀: asiwa ti ọkọnri na o sì buru jù ti iṣaju rẹ̀ lọ. O sì ṣe, bi o ti nsọ nkan wọnyi, obiri kan

Digitized by Google

nahùn ninu ijọ, o sì wi fu u pe, Ibukún ni fu inu ti o bí ọ, ati ọmú ti iwọ mu. Ṣugbọn o wipe, Nitõtọ, ki a kuku wipe, Ibukún ni fu awọn ti ngbọ́ ọ̀rọ Olọrun, ti nwọn sì npa a mọ́.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸRIN NI LENTI.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, fifu wa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ki awa, ti o yẹ ki a ṣẹ̀ nisẹ̀ nitori iṣe buburu wa, nipa itunu ore-ọfẹ rẹ ki a le ma fi ãnu rẹ dẹ̀ wa lara; nitori Jesu Kristi Oluwa ati Olugbala wa. *Amin.*

Episteli. Gal. 4. 21.

EWI fu mi, ẹnyin ti nfẹ wà labbẹ ofin, ẹnyin kò gbọ̀rọ ofin? Nitoriti a ti kọwe rẹ̀ wipe, Abrahamu li ọmmọkọnri meji, ekini nipa ẹrú-obiri, ekeji nipa omnira-obiri. Ṣugbọn a bí eyiti iṣe ti ẹrú-obiri nipa ti ara; ṣugbọn eyiti omnira-obiri li a bí nipa ileri. Awọn nkan ti iṣe apẹrẹ: nitoripe awọn wọnyi ni majẹmu meji ni; ekini lati ori ọ̀ke Sinai wá, ti a bí li oko-ẹrú, ti iṣe Hagari. Nitoripe Hagari yi ni ori ọ̀ke Sinai ni Arabia, ti o sì wà bakan na bi Jerusalemu ti o wà nisisiyi, ti o sì wà li oko-ẹrú pẹlu awọn ọmmọ rẹ̀. Ṣugbọn omnira ni Jerusalemu ti o wà loke, ti iṣe iya gbogbo wa. Nitoriti a ti kọwe rẹ̀ wipe, Ma yọ̀ iwọ àgan ti kò bímọ; bú ki o sì kigbe soke, iwọ ti kò rọbi ri; nitoripe ẹni alahoro li ọpọlọpọ ọmmọ jù ẹniti iṣe abilekọ lọ. Ṣugbọn awa, arakọnri, bi Isãki ti jasi, awa ni iṣe awọn ọmmọ ileri. Ṣugbọn bi igbana eyiti a bí nipa ti ara ti ṣe inunibini si eyiti a bí nipa ti Ẹmí, gẹgẹ bẽli o jasi nisisiyi. Ṣugbọn kini Iwe mimọ́ Olọrun wi? Lé ẹrú-obiri na jade ati ọmọkọnri rẹ̀: nitoripe ọmmọkọnri ti ẹrú-

Digitized by Google

obiri kì yio ba ọmmọkọnri ti omnira-obiri ṣe ajumọjogun pọ̀. Nitorina, arakọnri, awa kì iṣe ọmmọ ti ẹrú-obiri, bikoṣe ti omnira.

Ihin-rere. Joh. 6. 1.

JESU kọja si apakeji adagun Galili, ti ṣe adagun ti Tiberia. Ọpọ awọn enia sì ntọ ọ lẹhin, nitoriti nwọn ri iṣẹ iyanu rẹ̀, ti o ṣe si awọn ti ara wọn ṣe alaida. Jesu sì gùn ori òke lọ, nibẹ̀ li o sì gbé joko pẹlu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀. Ijọ irekọja, ajọ ti awọn Ju sì sumọ́ etile. Nigbati Jesu sì gbé oju rẹ̀ soke, ti o sì ri ọpọ awọn enia wá sọdọ rẹ̀, o wi fu Filipu pe, Nibo li a o ti rà akara, ki awọn wọnyi ki o le jẹ? O sì sọ eyi lati dan a wò; nitoriti on tikararẹ̀ mọ ohun ti on o ṣe. Filipu da a lohùn pe, Igba owo idẹ akara kò to fu wọn, ti olukuluku wọn iba fi mu diẹ diẹ. Ọkan ninu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀, Andru, arakọnri Simon Peteru wi fu u pe, Ọmmọkọnri kan mbẹ nihinyi, ti o ni iṣu akara Krite marun, ati ẹja kekere meji: ṣugbọn kili wọn-ni ninu ọpọ awọn enia wọnyi? Jesu sì wipe, Ẹ mu ki awọn enia na joko. Koriko pipo sì wà nibẹ̀. Bẹ̃li awọn ọkọnri na joko, ni kikà nwọn to ìwọn ẹgbẹ̀dọgbọn ẹnia. Jesu sì mu iṣu akara wọn-ni; nigbati o sì ti dupẹ, o pín wọn fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀, awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ sì pín wọn fu awọn ti o joko; bẹ̃ gẹgẹ sì li ẹja ni ìwọn bi nwọn ti nfẹ. Nigbati nwọn sì yó, o wi fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ pe, Ẹ kó ajẹkùn ti o kù jọ, ki ohunkohun máṣe ṣegun. Nitorina nwọn kó wọn jọ pọ̀, a sì kún agbọn mejila li ajẹkùn ti iṣu akara Krite marun, li eyi ti o ṣikùn, ti o sì pọ̀ju fu awọn ti o jẹ. Nitorina nigbati awọn ọkọnri na ri iṣẹ iyanu ti Jesu ṣe, nwọn wipe, Lõtọ eyi ni woli na ti mbọ̀ wá aiye.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKARUN NI LENTI.

Adura.

ỌLỌRUN Olodumare, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fi ãnu wò awọn enia rẹ; nipa ore rẹ nla ki a le ma ṣe akoso, ki a sì ma ṣe ipamọ́ wọn titi lai, ati li ara ati li ọkkàn; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Heb. 9. 11.

KRISTI ti wá lati ṣe olori alufa ohun rere ti mbọ̀, nipa agọ́ ti o ṣe nlaju ti o sì péju, ti a kò fi ọwọ́ pa, eyini ni pe, kì iṣe ti ikọle yi; bẹ̃ni kì iṣe nipasẹ ẹ̀jẹ ti ewurẹ ati ti ọmmọ malu, ṣugbọn bikoṣe nipa ẹ̀jẹ on tikararẹ̀ li o fi wọle lẹ̃kan sinu ibi mimọ́ ni, ti o sì ni idande ainipẹkun fu wa. Nitoripe bi ẹ̀jẹ ti akọ malu ati ti ewurẹ, ati ẽru ti ẹgbọrọ abo malu ti a nta si ara alaìmọ́, ba nyàni si mimọ́ si isọ ara di mimọ́: melomelo li ẹ̀jẹ ti Kristi, ẹni nipa Ẹmmí titi lai ti o fi ara rẹ̀ rubọ si Ọlọrun li aìni abawọn, yio wẹ̀ ọkkàn nyin nù mọ́ kuro ninu okú iṣẹ lati sìn Ọlọrun alãye? Ati nitori idi eyi li o ṣe di onilaja ti majẹmu titun, pe nipasẹ ikú, nitori idande ti irekọja ti o ti mbẹ labbẹ majẹmu iṣaju, awọn ti a ti pè ki o le ri ileri ijogún ainipẹkun gbà.

Ihin-rere. Joh. 8. 46.

JESU wipe, Tani ninu nyin ti o fi oyé ẹ̀ṣẹ yé mi? Bi o ba ṣepe otitọ ni mo wi, ẽṣe ti ẹnyin kò gbà mi gbọ́? Ẹniti ṣe ti Ọlọrun, a ma gbọ́ ọrọ Ọlọrun: ṣugbọn ẹnyin kò gbọ́ ọ, nitoriti ẹnyin kì iṣe ti Ọlọrun. Nigbana li awọn Ju dahùn, nwọn sì wi fu u pe, Awa kò wi nitõtọ pe, ara Samaria ni iwọ ṣe, ati pe iwọ li ẹ̀ṣu? Jesu dahùn wipe, Emi kò li ẹ̀ṣu;

Digitized by Google

ṣugbọn emi mbù ọllá fu Babba mi, ẹnyin sì ṣe àlbọllá fu mi. Emi kò wá ọllá ti emi tikara mi: ẹnikan wà ti o nwá ti o sì ndajọ. Lõtọ, lõtọ ni mo wi fu nyin, Bi ẹnikan ba pa ọ̀rọ mi mọ́, kì yio ri ikú lailai. Nigbana li awọn Ju wi fu u pe, Nigbayi li awa mọ pe iwọ li èṣu. Abrahamu kú, ati awọn woli; iwọ sì wipe, Bi ẹnikan ba pa ọ̀rọ mi mọ́, kì yio tọ́ ikú wò lailai. Iwọ pọ̀ju Abrahamu babba wa lọ, ẹniti o kú? ati awọn woli kú: tani iwọ nfi ara rẹ pè? Jesu dahùn wipe, Bi mo ba mbù ọllá fu ara mi, asan li ọllá mi: Babba mi ni ẹniti mbù ọllá fu mi; ẹniti ẹnyin wipe, Ọlọrun nyin ni iṣe: ṣugbọn ẹnyin kò mọ ọ; ṣugbọn emi mọ ọ; bi mo ba sì wipe, emi kò mọ ọ, emi o sì di eleke gẹgẹ bi ẹnyin: ṣugbọn emi mọ ọ, mo sì pa ọ̀rọ rẹ mọ́. Babba nyin, Abrahamu, yọ̀ lati ri ọjọ mi: o sì ri i, o sì yọ̀. Nigbana li awọn Ju wi fu u pe, Ọdún rẹ kò ti to adọta, iwọ sì ti ri Abrahamu? Jesu sì wi fu wọn pe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi fu nyin, Ki Abrahamu to wà, emi ni. Nigbana ni nwọn gbé okuta soke lati sọ lù u: ṣugbọn Jesu fi ara rẹ̀ pamọ́, o sì jade kuro ni tempeli.

ỌJỌ ỌLỌRUN TI O KANGUN ṢAJU AJINDE.

Adura.

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, ninu iyọnu ifẹ́ rẹ si araiye, iwọ ti o rán Ọmmọ rẹ, Jesu Kristi Olugbala wa, lati mu àwọ ara wa wọ̀, ati lati jìya ikú lori agbelebu, ki gbogbo araiye ki o le ma tọ̀pa apẹrẹ irẹlẹ rẹ̀ nla; Fi ãnu fifuni, ati ki awa ki o le ma tọ̀pa apẹrẹ sũru rẹ̀, ati pẹlu ki a le ṣe alabapin ajinde rẹ̀; nitori Jesu Kristi na Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. Fil. 2. 5.

JẸ ki ironu yi ki o wà ninu nyin, eyiti o ti wà pẹlu ninu Kristi Jesu: ẹniti o tilẹ jẹ aworan Ọlọrun, ti kò kà a si pe olè ni lati ba Ọlọrun dọgba: ṣugbọn kò fi ara rẹ̀ ṣe ẹni ọlọllá, o sì tẹwọgbà àwọ iranṣẹ fu ara rẹ̀, a sì bí i nipa aworan enia. Nigbati a sì ti ri i ni ìwa gẹgẹ bi ti enia, o rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ, o sì tẹriba titi di oju ikú, ani ikú lori agbelebu. Nitorina Ọlọrun sì ti gbé e le ibi gigagiga pẹlu, o sì ti fi orukọ kan fu u ti o bori gbogbo orukọ: pe li orukọ Jesu ni ki gbogbo ẽkun ki o ma kunlẹ, awọn ẹniti mbẹ li ọrun, ati awọn ẹniti mbẹ ni ilẹ, ati awọn ẹniti mbẹ nisalẹ ilẹ; ati pe ki gbogbo ahọn ki o ma jẹwọ pe, Jesu Kristi ni Oluwa, fu ogo Ọlọrun Babba.

Ihin-rere. Mat. 27. 1.

NIGBATI o di owurọ̀, gbogbo awọn olori alufa ati awọn alàgba enia gbìmọ si Jesu lati pa a: nigbati nwọn sì dè e tan, nwọn mu u lọ, nwọn sì fi i le Pontiu Pilatu lọwọ́ ti ṣe Bãlẹ. Nigbana ni Juda, ẹniti o fi i hàn, nigbati o ri pe a da lẹbi, on tikararẹ̀ ronupiwada, o sì tún mu ọgbọ̀n owo fadaka na pada wá, o sì fifu awọn olori alufa ati fu awọn alàgba, wipe, emi ṣẹ̀ li eyiti mo fi ẹ̀jẹ alaiṣẹ̀ hàn. Nwọn sì wipe, Kili eyi ohun si wa? mu oju rẹ to eyi ni. O sì da owo fadaka silẹ ni tempeli, o sì jade, o sì lọ so ara rẹ̀. Awọn olori alufa sì mu owo fadaka na, nwọn sì wipe, Kò tọ́ ki a fi i sinu owo iṣura, nitoripe iye owo ẹ̀jẹ ni. Nwọn sì gbìmọ, nwọn sì fi rà ilẹ amọ̀koko, lati ma sinkú awọn alejò ninu rẹ̀. Nitorina li a fi npè ilẹ na ni Ilẹ ẹ̀jẹ, titi o fi di ọjọ oni. Nigbana li eyi ti Jeremia woli sọ wa ṣẹ, ti o wipe, Nwọn sì mu ọgbọ̀n owo

Digitized by Google

fadaka, iye owo ẹniti a diyele, ẹniti awọn ọmmọ Israeli diyele; nwọn sì fi rà ilẹ amọ̀koko, gẹgẹ bi Oluwa ti làna silẹ fu mi. Jesu sì duro niwaju Bãlẹ: Bãlẹ sì bi i lẽre, wipe, Iwọ li Ọbba ti awọn Ju? Jesu sì wi fu u pe, Iwọ wi i. Nigbati a sì nkà si lọrùn lati ọwọ́ awọn olori alufa, ati awọn alàgba wá, on kò dahùn kan. Nigbana ni Pilatu wi fu u pe, Iwọ kò gbọ́ ọ̀pọ ohun ti nwọn njẽri si ọ? On kò sì da a ni gbolohun kan; niwọn tobẽ ti ẹnu yà Bãlẹ gidigidi. Nigba ajọ na, Bãlẹ a ti ma da ondè kan silẹ fu awọn enia, ẹnikẹni ti nwọn ba fẹ. Nigbana nwọn ni ondè buburu kan, ti a npè ni Baraba. Nitorina nigbati nwọn pejọ, Pilatu wi fu wọn pe, Tali ẹnyin nfẹ ki emi ki o da silẹ fu nyin? Baraba, tabi Jesu ti a npè ni Kristi? O sá ti mọ̀ pe nitori ilara ni nwọn ṣe fi i le on lọwọ́. Nigbati o sì joko lori itẹ́ idajọ, aya rẹ ranṣẹ si i, wipe, Máṣe li ọwọ́ si ọkọnri olododo ni: nitori ohun pipọ ni mo ri li oju alá loni nitori rẹ. Ṣugbọn awọn olori alufa, ati awọn alàgba yi ijọ awọn enia li ọkkàn pada si ati bère Baraba, ki o sì pa Jesu. Bãlẹ dahùn o sì wi fu wọn pe, Ninu awọn mejeji, ewo li ẹnyin nfẹ ki emi ki o da silẹ fu nyin? Nwọn wipe, Baraba. Pilatu bi wọn pe, Kili emi o ha ṣe si Jesu, ẹniti a npè ni Kristi? Gbogbo wọn sì wi fu u pe, Jẹ ki a kàn a mọ́ agbelebu. Bãlẹ sì bère wipe, Ẽṣe idi rẹ, buburu kili o ṣe? Ṣugbọn nwọn kigbe soke tobẽ jù lọ, wipe, Jẹ ki a kàn a mọ́ agbelebu. Nigbati Pilatu ri pe, on kò le bori li ohunkohun, ṣugbọn pe a kuku sọ gbogbo rẹ̀ di ariwo, o bu omi, o sì wẹ̀ ọwọ́ rẹ̀ li oju ijọ awọn enia, o wipe, Ọrùn mi mọ́ nipa ẹ̀jẹ ti enia olõtọ yi: ki ẹnyin kiyesi i. Nigbana ni gbogbo awọn enia dahùn,

Digitized by Google

nwọn sì wipe, Èjẹ rẹ̀ wà li ori wa, ati li ori awọn ọmmọ wa. Nigbana li o da Baraba silẹ fu wọn. Nigbati o sì nà Jesu tan, o fà a le wọn lọwọ́ lati kàn a mọ́ agbelebu. Nigbana li awọn ọmmọ ogun ti Bãlẹ mu Jesu lọ si ibi gbàngan idajọ, nwọn sì kó gbogbo awọn ọmmọ ogun tì i. Nwọn sì bọ ọ li aṣọ rẹ̀, nwọn sì wọ̀ ọ li aṣọ igunwà ododó. Nigbati nwọn ti wọ́n ade ẹgún tan, nwọn sì fi de e li ori, nwọn fi ọpá lye le e li ọwọ́ ọtún: nwọn sì kunlẹ niwaju rẹ̀, nwọn nsin i jẹ, wipe, Alafia, ọbba ti awọn Ju. Nwọn sì tutọ́ si i lara, nwọn sì gbà ọpá lye na, nwọn sì fi lù u li ori. Lẹhin igba ti nwọn sin i jẹ tan, nwọn bọ aṣọ igunwà na kuro lara rẹ̀, nwọn sì fi aṣọ rẹ̀ wọ̀ ọ, nwọn sì mu u jade lọ lati kàn a mọ́ agbelebu. Bi nwọn sì ti jade, nwọn ri ọkọnri kan ti ṣe ara Kirene, Simon li orukọ rẹ̀: on ni nwọn fi agbara mu lati rù agbelebu rẹ̀. Nigbati nwọn de ibi ti a npè ni Golgota, eyini ni pe, Ibi agbari, nwọn fi ọti kikan ti a dàpọ mọ́ pẹlu orõro fu u lati mu: nigbati o sì tọ́ ọ wò, on kò sì le mu u. Nwọn sì kàn a mọ́ agbelebu, nwọn sì pín aṣọ rẹ̀, nwọn sì ṣẹ́ gege rẹ̀: ki eyi ti woli wi ba le ṣẹ, Nwọn pín aṣọ mi fu ara wọn, aṣọ ileke mi ni nwọn ṣẹ́ gege le. Nwọn sì joko, nwọn nṣọ́ ọ nibẹ̀; nwọn sì fi òran ifisọ̀n rẹ̀ ti a kọ si igberi rẹ̀, EYI NI JESU ỌBBA TI AWỌN JU. Nigbana li a kàn awọn olè meji mọ́ agbelebu pẹlu rẹ̀, ọkan li ọwọ́ ọtún, ati ekeji li ọwọ́ òsin. Awọn ti nrekọja lọ sì nfi i ṣe ẹlẹyà, nwọn sì nmì ori wọn, wipe, Iwọ ti o wó tempeli, ti o sì kọ́ ọ ni ijọ mẹta, gbà ara rẹ là. Bi iwọ iba ṣe Ọmmọ Ọlọrun, sọkalẹ lati ori agbelebu wá. Gẹgẹ bẽli awọn olori alufa pẹlu awọn akọwe, ati awọn alàgba nsin i jẹ wipe, O ngbà awọn

Digitized by Google

ẹlomiran là; on tikararẹ̀ ni kò le gbala. Bi iba ṣe Ọbba Israeli, jẹ ki o sọkalẹ lati ori agbelebu wá nisisiyi, awa yio sì gbà a gbọ́. O gbẹ̀kẹ̀le Ọlọrun; ẹ jẹ ki o gbà a là nisisiyi, bi o ba ṣepe yio ri i: o sá wipe, Ọmmọ Ọlọrun li emi. Ati awọn olè ti a kàn mọ́ agbelebu pẹlu rẹ̀, nwọn sì nfi eyi na gún u loju bakan na. Lati wakati ẹkẹfa, òkunkun sì ṣú bò gbogbo ilẹ̀ titi o fi di wakati ẹkẹsan ọjọ́. Nigba wakati ẹkẹsan ni Jesu sì kigbe soke li ohùn rara wipe, Eli, Eli, lama sabaktani? eyini ni pe, Ọlọrun mi, Ọlọrun mi, ẽṣe ti iwọ fi kọ̀ mi silẹ? Nigbati awọn ọkan ninu awọn ti o duro nibẹ̀ gbọ́ eyi, nwọn wipe, Ọkọnri yi npè Elia. Lojukan na ọkan ninu wọn sare, o mu spunge, o tẹ ẹ bọ ọti kikan, o fi le ori ọpá ìye, o fifu u mu. Awọn iyokun wipe, Ẹ jọwọ rẹ̀ si, ẹ jẹ ki a ma wò o bi Elia yio wá gbà a là. Nigbati Jesu tún kigbe li ohùn rara, o jọwọ ẹmmí rẹ̀ lọwọ́. Sì kiyesi i, aṣọ ikele ti ile Ọlọrun (tempeli) fà ya ni meji lati oke de isalẹ; ilẹ̀ mì-titi, okuta sì sán; isà okú sì ṣí silẹ; ọpọ okú ninu awọn ẹni mimọ́ ti o ti sùn jinde, nwọn ti inu isà okú wọn jade lẹhin ajinde rẹ̀, nwọn sì wá si ilu mimọ́, nwọn fi ara hàn ọpọlọpọ enia. Nigbati ibalogun ọrún, ati awọn ti o wà pẹlu rẹ̀, ti nwọn nṣọ Jesu, ri iṣẹlẹ na, ati ohun wọn-ni ti a sì ṣe, ẹ̀ru ba wọn gidigidi, nwọn wipe, Lõtọ Ọmmọ Ọlọrun li eyi ṣe.

MONDAY TI O ṢAJU (EASTER) AJINDE.

Episteli. Isa. 63. 1.

TA li eyi ti nti Edọmu jade bọ̀, ti on ti aṣọ ti ara lati Bọsra wá? eyiti o li ogo lara

Digitized by Google

aṣọ rẹ̀, ti nrìn ninu ọpọ agbara rẹ? Emi ti nsọrọ ninu ododo ni alagbara ni igbala. Eha ti ṣe ti iwọ fi pọn bẹ̃ lara aṣọ rẹ ati èwu rẹ bi ẹniti ntẹ̀ ninu ifọnti? Emi nikanṣoṣo ni mọtẹ̀ ifọnti ni, ati ninu enia kò si ẹnikan pẹlu mi; emi yio sa tẹ̀ mọlẹ ninu ibinu mi: emi o sì tè wọn rẹ ni irunu mi, ẹjẹ̀ wọn yio sì ta si ara aṣọ mi nwọn-ni emi o sì ṣọ gbogbo aṣọ mi di abawọn. Nitoriti ọjọ ẹsan mbẹ ninu mi, ati ọjọ idakurọnidè awọn enia mi idakurọnide de. Emi sì wò kò sì si ẹnikan lati ṣe iranlọwọ; ẹnu sì ya mi ti kò si ẹnikan lati ṣe atilẹhin: nitorina li apa ti ara mi mu igbala tọ̀ mi wá, ati irunu mi o tì mi lẹhin. Emi o sì tẹ̀ awọn enia na mọlẹ ni ibinu mi, emi o sì fi fu wọn mu mi irunu mi, emi o sì ṣọ agbara wọn kalẹ yi ilẹ. Emi yio sọrọ iṣeun ifẹ̀ Oluwa, ati iyin Oluwa, gẹgẹ bi gbogbo eyiti Oluwa fifu wa, ati ore nla si awọn aralẹ Israeli, ti o fi fu wọn gẹgẹ bi anu rẹ̀, ati gẹgẹ bi ọpọlọpọ iṣeun ifẹ̀ rẹ. Nitoriti o wipe, Nitotọ enia mi ni wọn, awọn ọmmọ ti kò jẹ ṣeke; bẹ̃li on ṣe Olugbala wọn. Ninu ipọnju wọn gbogbo on ṣe ipọnju, angeli iwaju rẹ̀ sì gbà wọn là: ninu ifẹ̀ rẹ̀ ati ninu iyọnu rẹ̀ ọrà wọn silẹ, o sì rù wọn, o sì ko wọn lọ li ọjọ igbani gbogbo. Ṣugbọn nwọn ṣọtẹ, nwọn sì mu Ẹmmí Mimọ rẹ̀ binu; nitorina li o ṣe yipada di ọtá wọn o sì ba wọn jà. Nigbana li o ranti ọjọ atijọ, Moses ati awọn enia rẹ̀ pe, Niboni ẹniti o mu wọn jade ti okun wa gbe wà pẹlu oluṣọ agbo enia rẹ̀? nibo li ẹniti o fi Ẹmmí Mimọ rẹ̀ si i ninu gbé wà? ẹniti o ṣe amọna wọn nipa ọwọ́ ọtún Moses, pẹlu apa rẹ̀ ti o li ogo, ti o npin omi niya niwaju wọn lati ṣọ ara rẹ̀ li Orukọ titi aiye? ẹniti o ṣe amọna la ibú já bi ẹnipe ẹṣin nilẹ

Digitized by Google

aganju ki nwọn ki o ma ba ṣubu? Bi ẹranko ti isọkale lọ si afonifoji Ẹmmí Oluwa mu u simi: bẹ̃ni iwọ ṣe amọna awọn enia rẹ lati sọ ara rẹ li orukọ ti o li ogo. Wolẹ lati ọrun wá ki o sì wò lati bujoko iwà mimọ́ re wá, ati ti ogo rẹ: nibo ni itara rẹ wà ati agbara rẹ, iro inu rẹ ati ti anu rẹ si mi. A da wọn duro? Lai ṣani-ani iwọ ni Babba wa, bi Abrahamu tilẹ ṣalàmọ wa, ti Israeli kò sì jẹwọ wa: Iwọ Oluwa ni Babba wa, Oludande wa, lati aiyeraiye li Orukọ rẹ. Oluwa ẽṣe ti iwọ mu wa ṣìna kuro nipa ọna rẹ? ti o sì ṣe àiya wa le kuro nipa ibẹru rẹ. Nitoriti iranṣẹ rẹ mu ẹ̀ya awọn enia ilẹ rẹ pada. Awọn enia iwà mimọ rẹ ni i nigba diẹ sa ni: awọn ọtá wa ti tẹ̀ sanktuari rẹ mọlẹ. Awa ni tirẹ: iwọ kò ṣe akoso wọn ri; a kò fi Orukọ rẹ mimọ pè wọn.

Ihin-rere. Marku 14. 1.

LẸHIN ọjọ meji ni ijọ irekọja, ati ti aìwukara: ati awọn olori alufa ati awọn akọwe nwá ọna bi nwọn iba ti fi ẹ̀tan mu u, ki nwọn ki o pa a. Ṣugbọn nwọn wipe, Kì iṣe li ọjọ ajọ, ki ariwo ki o má ba wà ninu awọn enia. Nigbati o sì wà ni Betani ni ile Simon adẹtẹ, bi o ti joko tì onjẹ, obiri kan ti o ni èba (oruba) alabasta turari tutù iyebiye pọ́, o wá, o sì fọ́ èba na, o sì ndà a si i lori. Awọn ọkan sì wà ti inu wọn ru ninu ara wọn, nwọn sì wipe, Nitoriti kili a ṣe nfi turari yi ṣòfo? A ba sá tà turari tutù yi jù ìwọn ọdọrun owo idẹ lọ, a ba sì fifu awọn talakà. Nwọn sì nkù si i. Ṣugbọn Jesu wipe, Ẹ jọwọ rẹ̀ si; ẽṣe ti ẹnyin fi mba a wi? iṣẹ rere li o ṣe si mi lara. Nigba-gbogbo li ẹnyin sá ni talakà pẹlu nyin, ki ẹnyin ki o sì ma ṣore fu wọn

Digitized by Google

nigbakugba ti ẹnyin fẹ; ṣugbọn ẹnyin kò ni mi nigba-gbogbo. O ṣe ìwọn eyi ti o le ṣe: o wá ṣiwaju lati fi oróro kùn ara mi fu sisin. Lõtọ ni mo wi fu nyin, Nibikibi ti a o gbé wasu ihin rere yi ni gbogbo aiye, nibẹ̀ pẹlu li a o sì rò ihin eyi ti obiri yi ṣe lati fi ṣe iranti rẹ̀. Juda Iskariotu ọkan ninu awọn mejejila, sì tọ̀ awọn olori alufa lọ, lati fi i hàn fu wọn. Nigbati nwọn sì gbọ́, nwọn yọ̀ gidigidi, nwọn sì ṣe ileri lati fu u li owo. O sì nwá ọ̀na lati fi i hàn. Li ọjọ́ ekini ti ijọ́ aìwukara, nigbati nwọn npa ẹran irekọja, awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ sì wi fu u pe, Nibo ni iwọ nfẹ ki a pèse silẹ dè ọ, ki iwọ ki o le jẹ irekọja. O sì rán awọn meji ninu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀, o sì wi fu wọn pe, Ẹ lọ si ilu nla, ọkọnri kan ti nrù ìṣa omi yio pade nyin: ẹ ma tọ̀ ọ lẹhin. Ati ibikibi ti o ba gbé wọ̀, ki ẹnyin ki o wi fu bãle ẹni rere na pe, Olukọni wipe, Nibo ni gbàngan apejẹ na gbé wà, nibiti emi o gbé jẹ irekọja pẹlu awọn ọmmọ ẹhin mi? On yio sì fi gbàngan nla kan loke hàn nyin, ti a ṣe lọṣọ, ti a sì pèse tẹlẹ; nibẹ̀ ni ki ẹnyin ki o pèse silẹ dè wa. Awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ sì jade lọ, nwọn wá si ilu nla, nwọn sì ri i gẹgẹ bi o ti sọ fu wọn: nwọn sì pèse irekọja silẹ. Nigbati alẹ sì lẹ, o wá pẹlu awọn mejejila. Bi nwọn sì ti joko ti nwọn njẹun, Jesu wipe, Lõtọ ni mo wi fu nyin, Ọkan ninu nyin ti mba mi jẹun pọ̀ yio fi mi hàn. Nwọn sì bẹ̀rẹ si ikãnu gidigidi, ati si ibi i lẽre lọkọkan wipe, Iṣe emi ni bi? ekeji sì wipe, Iṣe emi ni bi? O sì dahùn o sì wi fu wọn pe, Ọkan ninu awọn mejejila, ti o ntọwọ́ bọ inu awo pẹlu mi ni. Nitõtọ Ọmmọ ọkọnri nlọ bi a ti kọwe nipa ti rẹ̀: ṣugbọn egbé ni fu ọkọnri na, lọdọ ẹniti a gbé ti fi Ọmmọ ọkọnri hàn! iba san

Digitized by Google

fu ọkọnri na, bi o ṣepe a kò bí i. Bi nwọn sì ti njẹun, Jesu mu akara, o sì sure, o sì bu u, o sì fifu wọn, o wipe, Gbà, jẹ: eyiyi li ara mi. O sì mu ago, nigbati o sì sure tan, o fifu wọn: gbogbo nwọn sì mu ninu rẹ. O sì wi fu wọn pe, Eyi li ẹ̀jẹ mi ti majẹmu titun, eyi ti a tà silẹ fu ọpọ enia. Lõtọ ni mo wi fu nyin, emi kì yio sì mu ninu eso ajara mọ́, titi yio fi di ọjọ na, nigbati emi o sì mu u ni titun ni ijọba Ọlọrun. Nigbati nwọn sì kọn orin kan tan, nwọn jade lọ sori òke Olifi. Jesu sì wi fu wọn pe, Gbogbo ẹnyin ni yio ṣe àkẹhinda si nitori mi li alẹ yi: nitoriti a ti kọwe rẹ̀ pe, Emi o kọlù oluṣọ agutan, a o sì tú agbo agutan na ká kiri. Ṣugbọn lẹhin igba ti mo ba tũn jinde, emi o sì ṣaju nyin lọ si Galili. Ṣugbọn Peteru wi fu u pe, Bi gbogbo enia tilẹ ṣe àkẹhinda si, ṣugbọn emi kì yio ṣe àkẹhinda si. Jesu sì wi fu u pe, Lõtọ ni mo wi fu ọ pe, Li oni yi, ani li alẹ yi kan na, ki akukọ ki o to kọ nigba meji, iwọ yio sẹ́ mi nigba mẹta. Ṣugbọn o tilẹ tẹnumọ ọ gidigidi wipe, Bi o tilẹ di ati ba iwọ kú, emi kò jẹ sẹ́ ọ bi o ti wù ki o ri. Gẹgẹ bẽni gbogbo wọn sì wi pẹlu. Nwọn sì wá si ibi kan ti a npè ni Getsemane: o sì wi fu awọn ọmọ ẹhin rẹ̀ pe, Ẹ joko nihinyi, nigbati emi o lọ igbadura. O sì mu Peteru ati Jakobu ati Johanu pẹlu rẹ̀, o sì bẹ̀rẹ si ima kãnu, o sì bẹ̀rẹ si irẹ̀ ẹ gidigidi; o sì wi fu wọn pe, Ọkkàn mi nkãnu gidigidi titi de ti ikú: ẹ duro nihinyi, ki ẹ sì ma ṣọna. O sì lọ siwaju diẹ, o sì wolẹ, o sì ngbadura pe, bi o ba le ṣe, ki wakati na ki o le kọja kuro lori rẹ̀. O sì wipe, Aba, Babba, ṣiṣe li ohun gbogbo fu ọ; mu ago yi kuro lori mi: ṣugbọn kì ma ṣe eyiti emi nfẹ, bikoṣe eyiti iwọ fẹ. O sì wá, o ba wọn, nwọn nsùn,

Digitized by Google

o sì wi fu Peteru pe, Simon, iwọ nsùn? iwọ kò le bá mi ṣọna ni wakati kan? Ẹ ma ṣọna, ki ẹnyin ki o sì ma gbadura, ki ẹnyin ki o má ba bọ sinu idẹwò. Lõtọ li ẹmmí nfẹ, ṣugbọn o ṣe alaìlera fu ara. O sì tún pada lọ, o sì gbadura, o sì sọ ọrọ kan na. Nigbati o sì pada wá, o tún bá wọn, nwọn nsùn, (nitoriti oju wọn kun fu orun,) bẽni nwọn kò sì mọ èsin ti nwọn iba fifu u. O sì wá li arinkẹta, o sì wi fu wọn pe, Ẹ ma sùn wayi, ki ẹnyin sì ma simi: o to bẽ, wakati na de; kiyesi i, a fi Ọmmọ ọkọnri le si ọwọ awọn ẹlẹṣẹ. Ẹ dide, ki a ma lọ; wò o, ẹniti o fi mi hàn sumọ ọdọ wa. Lojukan na, bi o sì ti nsọ lọwọ, Juda de, ọkan ninu awọn mejejila, ati ọpọ enia pẹlu rẹ ti awọn ti idà, pẹlu ọgọ, lati ọdọ olori awọn alufa, ati awọn akọwe, ati awọn alàgba wá. Ẹniti o sì fi i hàn ti fi àmi fu wọn, wipe, Ẹnikẹni ti mo ba fi ẹnu kò li ẹnu, on na ni; ki ẹnyin ki o mu u, ki ẹ sì ma fà a lọ li alafia. Nisisiyi bi o ti de, o sì tọ ọ lọ lojukan na, o wi fu u pe, Olukọni olukọni; o sì fi ẹnu kò o li ẹnu. Nwọn sì gbé ọwọ wọn le e, nwọn sì mu u. Ọkan ninu awọn ti o duro nibẹ fà idà yọ, o sì ṣá ọkan ti ṣe iranṣẹ ti olori alufa, o sì ke etí rẹ sọnù. Jesu sì dahùn o sì wi fu wọn pẹ, Emi li ẹnyin jade tọ wá bi olè, ti ẹnyin ti idà ati ọgọ lati mu? Li ojojumọ li emi wà pẹlu nyin ni ile Ọlọrun (tempeli,) ti emi nkọ nyin, ẹnyin kò sì mu mi: ṣugbọn Iwe mimọ Ọlọrun kò le ṣe alaìṣẹ. Gbogbo wọn sì fi i silẹ, nwọn sì sá lọ. Ọmmọkọnri kan sì ntọ ọ lẹhin, ti o fi aṣọ ọgbọ àla bò ìhoho ara rẹ; awọn ọmmọkọnri sì gbá a mu: O sì jọwọ aṣọ ọgbọ àla na lọwọ, o sì sá kuro lọdọ wọn nihoho. Nwọn sì mu Jesu lọ sọdọ olori awọn alufa: gbogbo awọn

Digitized by Google

olori alufa, ati awọn alàgba, ati awọn akọwe sì pejọ pẹlu rẹ̀. Peteru sì tọ̀ ọ lẹhin li òkere titi fi de agbala ti olori awọn alufa; o sì bá awọn onisẹ̀ na joko, o sì nyána. Awọn olori alufa ati gbogbo ijọ ìgbimọ nwá ilẽri si Jesu lati pa a; nwọn kò si ri ohun kan. Nitoripe ọpọlọpọ li o jẽri eke si i, ṣugbọn ohùn awọn elẽri na kò ṣọkan. Awọn ọkan sì dide, nwọn njẽri eke si i, wipe, Awa gbọ́ o wipe, Emi yio wó tempeli yi ti a fi ọwọ́ ṣe, niwọn ijọ mẹta emi o sì kọ́ omiran ti a kò fi ọwọ́ ṣe. Ati ninu eyi na pẹlu, ohùn wọn kò ṣọkan. Olori awọn alufa sì dide duro larin, o sì bi Jesu lẽre, wipe, Iwọ kò dahùn kan? kili eyi ti awọn wọnyi njẽri si ọ? Ṣugbọn Jesu dakẹ, kò si dahùn ohun kan. Olori awọn alufa sì tún bi i lẽre, o wi fu u pe, Iwọ ni Kristi na, Ọmọ ti Olubukún ni? Jesu sì wipe, Emi ni: ẹnyin o sì ri Ọmọ ọkọnri yio joko li ọwọ́ ọtún agbara, yio sì ma ti inu awọ sanma ọrun wá. Nigbana li olori awọn alufa fà aṣọ rẹ̀ ya, o wipe, Ẹlẽri kili a sì nwá? Ẹnyin ti gbọ́ ọrọ òdi si Ọlọrun na: ẹnyin ti rò o si? Gbogbo wọn sì da a lẹbi pe, o jọbi ikú. Awọn omiran sì bẹ̀rẹ si itutọ́ si i lara, ati si ibò o loju, ati si ikàn a lọṣẹ́, nwọn sì wi fu u pe, Sọtẹlẹ: awọn iranṣẹ sì nfi atẹlẹ ọwọ́ wọn gbá a loju. Bi Peteru sì ti wà ni isalẹ li ãfin, ọkan ninu awọn ọmọbiri ti olori awọn alufa wá: nigbati o sì ri ti Peteru nyána, o wò o, o sì wipe, Iwọ sì wà pẹlu Jesu ti Nasareti. Ṣugbọn o sẹ́, wipe, Emi kò mọ̀, oyé ohun ti iwọ nwi kò tilẹ yé mi. O sì jade lọ si iloro; akukọ sì kọ. Ọmọbiri kan sì tún ri i, o sì bẹ̀rẹ si iwi fu awọn ti o duro nibẹ̀ pe, Ọkan ninu wọn ni eyi. O sì tún sẹ́ ẹ. O sì pẹ diẹ, awọn ti o duro nibẹ̀ tún wi fu Peteru pe,

Digitized by Google

Lẹ́tọ ni ọkan ninu wọn ni iwọ ṣe: nitoripe ara Galili ni iwọ, ohùn rẹ sì jọ bẹ́ẹ̀. Ṣugbọn o bẹ̀rẹ si iré ati si ibura, wipe, Emi kò mọ̀ ọkọnri yi ẹniti ẹnyin nwi. Akukọ sì kọ larinkeji. Peteru sì ranti ọ̀rọ ti Jesu wi fu u pe, Ki akukọ ki o to kọ larinmeji, iwọ o sẹ́ mi larinmẹta. Nigbati o si rò o, o sọkun.

TUESDAY TI O ṢAJU (EASTER) AJINDE.

Episteli. Isa. 50. 5.

OLỌRUN Oluwa ṣi mi li etí, emi kò sì ṣe alaìgbọran bẹ́ẹ̀li emi kò sì pẹhinda. Emi fi ẹhin fu awọn aluni, ati ẹrẹkẹ mi fu awọn afani ni irun tu: Emi kò sì pa oju mi mọ́ kuro ninu itiju ati itutọ si. Nitoripe Ọlọrun Oluwa ni yio ran mi lọwọ́ nitorina li emi kì yio ṣe damu: nitorina ni mo ṣe gbé oju mi duro bi okuta ibọn, emi sì mọ̀ pe oju kì yio tì mi. Ẹniti ndani lare mbẹ nitosi; tani yio ba mi ṣe aroye? E' jẹ ki a jùmọ duro; ta ni iṣe ọtá mi? jẹ ki o sunmọdọ mi. Kiye si i, Ọlọrun Oluwa ni yio ràn mi lọwọ́; tani yio da mi li ẹbi? Kiyesi i gbogbo nwọn ni yio di ogbologbo bi ẹwu: ola yio sì mu nwọn jẹ. Ta ni ninu nyin ti ọ bẹ̀ru Oluwa, ti ọ gbà ohun iranṣẹ rẹ gbọ, ti o nrìn ninu okunkun ti kò sì ni imọlẹ ki o gbẹkele Orukọ Oluwa, ki o sì fi ara tì Ọlọrun rẹ̀. Kiye si i gbogbo ẹnyin ti nda ina, ti ẹ sì fi tita ina yi ara nyin ka, ẹ ma rìn ninu imolẹ ina nyin, ati ni tita ina ti ẹnyin da. Eyi li ẹnyin ori gbà lọwọ́ mi, ẹnyin yio dubulẹ ninu ibinujẹ.

Ihin-rere. Marku 15. 1.

LOJUKAN na li owurọ̀, awọn olori alufa jọ gbìmọ pẹlu awọn alàgba, ati awọn

Digitized by Google

akọwe, ati gbogbo ijọ ìgbimọ, nwọn sì dè Jesu, nwọn sì mu u lọ, nwọn sì fi i le Pilatu lọwọ́. Pilatu sì bi i lẽre, wipe, Iwọ li Ọbba ti awọn Ju? O sì dahùn wi fu u pe, Iwọ wi i. Ati awọn olori alufa sì fi i sọ̀n li ohun pipọ: ṣugbọn on kò dahùn kan. Pilatu sì tún bi i lẽre, wipe, Iwọ kò dahùn ohun kan? wò ọ̀pọ ohun ti nwọn njẽri si ọ. Ṣugbọn Jesu kò da a ni gbolohùn kan; tobẽ ti ẹnu yà Pilatu. Nigba ajọ na, on a ma da ondè kan silẹ fu wọn, ẹnikẹni ti nwọn ba fẹ. Ẹnikan sì wà ti a npè ni Baraba, ẹniti a sọ sinu tubu pẹlu awọn ti o ṣọ̀tẹ pẹlu rẹ̀, awọn ẹniti o sì pania pẹlu ninu ìṣọ̀tẹ na. Ijọ awọn enia sì bẹ̀rẹ si ikigbe soke li ohùn rara, nwọn nfẹ ki o ṣe bi on ti ima ṣe fu wọn ri, ṣugbọn Pilatu da wọn lohùn, wipe, Ẹnyin nfẹ ki emi ki o da Ọbba ti awọn Ju silẹ fu nyin? On sá ti mọ̀ pe nitori ilara ni awọn olori alufa ṣe fi i le on lọwọ́. Ṣugbọn awọn olori alufa gbé awọn enia soke pe, ki o kuku da Baraba silẹ fu wọn. Pilatu sì dahùn o tún wi fu wọn pe, Kili ẹnyin ha nfẹ ki emi ki o ṣe si ẹniti ẹnyin npè li Ọbba ti awọn Ju? Nwọn sì tún kigbe soke, wipe, Kàn a mọ́ agbelebu. Nigbana ni Pilatu sì bi wọn lẽre, wipe, Ere idi rẹ̀, buburu kili o ṣe? Nwọn sì kigbe soke gidigidi, wipe, Kàn a mọ́ agbelebu. Bẽni Pilatu sì nfẹ ṣe eyi ti o wù awọn enia, o da Baraba silẹ fu wọn. Nigbati o sì nà Jesu tan, o fà a le wọn lọwọ́ lati kàn a mọ́ agbelebu. Awọn ọmmọ ogun sì fà a jade lọ sinu gbàngan, ti a npè ni Pretorion; nwọn sì pè gbogbo ẹgbẹ awọn ọmmọ ogun jọ. Nwọn sì fi aṣọ elesè àluko wọ̀ o, nwọn wún ade ẹgún, nwọn sì fi de e li ori, nwọn sì bẹ̀rẹ si ikí i, wipe, Alafia, Ọbba ti awọn Ju! Nwọn sì fi ọpá ìye lù u lori,

Digitized by Google

nwọn sì tutọ́ si i lara, nwọn sì kunlẹ̀ niwaju rẹ̀, nwọn sì foribalẹ̀ fu u. Nigbati nwọn sì sin i jẹ̀ tan, nwọn sì bọ̀ aṣọ elesè àluko na kuro lara rẹ̀, nwọn sì fi aṣọ rẹ̀ wọ̀ ọ, nwọn sì mu u jade lọ lati kàn a mọ́ agbelebu. Nwọn sì fi agbara mu ọkọnri kan, Simon ara Kirene, ẹniti nkọja lọ, ti nti igberiko ibọ̀, babba ti Aleksanderu ati ti Rufu, lati rù agbelebu rẹ̀. Nwọn sì mu u wá si ibi ti a npè ni Golgota, ni itumọ̀ rẹ̀ eyini ni, Ibi agbari. Nwọn sì fi ọti wain ti a dàpọ̀ mọ́ pẹlu ojia fu u lati mu: ṣugbọn on kò gbà a. Nigbati nwọn sì kàn a mọ́ agbelebu tan, nwọn sì pín aṣọ rẹ̀, nwọn sì nṣẹ̀ gege lori wọn, èyi ti olukuluku iba mu. Ni wakati ẹkẹta ọjọ́, on ni nwọn sì kàn a mọ́ agbelebu. A sì kọwe akọle ọ̀ran ifisọ̀n rẹ̀ si igberi rẹ̀, ỌBBA TI AWỌN JU. Nwọn sì kàn awọn olè meji mọ́ agbelebu pẹlu rẹ̀; ọkan li ọwọ́ ọtún, ati ekeji li ọwọ́ òsin rẹ̀. Iwe mimọ́ Ọlọrun sì ṣẹ, ti o wipe, A sì kà a pẹlu awọn arufin. Awọn ti nrekọja lọ sì nfi i ṣe ẹlẹyà, nwọn sì nmì ori wọn, wipe, Ã, Iwọ ti o wó tempeli, ti o sì kọ́ ọ ni ijọ́ mẹta, gbà ara rẹ̀ là, ki o sì sọkalẹ̀ lati ori agbelebu wá. Gẹgẹ bẽli awọn olori alufa pẹlu, nwọn nsin i jẹ̀ ninu ara wọn pẹlu awọn akọwe, wipe, O gbà awọn ẹlomiran là; kò le gbà ara rẹ̀ là. Jẹ̀ ki Kristi Ọbba Israeli sọkalẹ̀ lati ori agbelebu wá nisisiyi, ki awa ki o le ri i, ki a sì le gbagbọ́. Awọn ti a kàn mọ́ agbelebu pẹlu rẹ̀ sì nfi i ṣe ẹlẹyà. Nigbati o sì di wakati ẹkẹfa, òkunkun sì ṣú bò gbogbo ilẹ̀ titi o fi di wakati ẹkẹsan ọjọ́. Ni wakati ẹkẹsan ni Jesu sì kigbe soke li ohùn rara, wipe, Eloi, Eloi, lama sabaktani? itumọ̀ eyi ti ṣe, Ọlọrun mi, Ọlọrun mi, ẽṣe ti iwọ fi kọ̀ mi silẹ̀? Nigbati awọn ọkan ninu awọn ti o

Digitized by Google

duro nibẹ gbọ́ eyi, nwọn wipe, Wò o, o npè Elia. Ẹnikan sì sare, o fi spunge bọ ọti kikan, o fi le ori ọpá lye, o fifu u mu, wipe, Ẹ jọwọ rẹ̀ si; ẹ jẹ ki a ma wò o bi Elia yio wá gbé e sọkalẹ. Jesu sì kigbe soke li ohùn rara, o jọwọ ẹmmí rẹ̀ lọwọ́. Aṣọ ikele ti ile Ọlọrun (tempeli) sì fà ya ni meji lati oke de isalẹ. Nigbati ibalogun ọrún, ti o duro niha ọdọ rẹ̀, ri ti o kigbe soke bayi, ti o sì jọwọ ẹmmí rẹ̀ lọwọ́, o wipe, Lõtọ Ọmmọ Ọlọrun li ọkọnri yi ṣe.

WEDNESDAY TI O ṢAJU (EASTER) AJINDE.

Episteli. Heb. 9. 16.

NIBITI iwe majẹmu gbé wà, ikú ti onimajẹmu kò le ṣe alsi pẹlu. Nitoripe iwe majẹmu li agbara lẹhin igbati enia ba kú tan: bikoṣe bẹ̃ on kò li agbara rara nigbati onimajẹmu mbẹ lãye. Njẹ nitori eyi na li a kò sì ṣe yà majẹmu iṣaju si mimọ́ li alni ẹjẹ. Nitoripe nigbati Mose ti sọ́ro olukuluku ofin fu gbogbo awọn enia gẹgẹ bi ofin, o mu ẹjẹ ti ọmmọ malu ati ti ewurẹ, pẹlu omi, ati owu ododó, ati ewe hisopu, o sì fi wọn ati iwe ati gbogbo awọn enia, on wipe, Eyiyi li ẹjẹ ti majẹmu ti Ọlọrun ṣe laṣe fu nyin. Pẹlupẹlu o fi ẹjẹ wọ́n ati agọ́, ati gbogbo ohun èlo ti lsin alufa. O sì fẹrẹ iṣe ohun gbogbo nipa ofin li a fi ẹjẹ wẹ̀numọ; ati li alta ẹjẹ silẹ imu kuro ẹṣẹ kò si. Nitorina o yẹ ki a fi nwọnyi wẹ̀ nkan ti ṣe apẹrẹ ti ohun ọrun nù; ṣugbọn ohun ọrun tikara wọn ki a fi ẹbọ ti o darajù nwọnyi lọ wẹ̀ wọn nù. Nitoripe Kristi kò wọ́ inu ibi mimọ́ wọn-ni lọ ti a fi ọwọ́ ṣe, ti iṣe apẹrẹ ti otitọ; ṣugbọn bikoṣe o lọ si ọrun

Digitized by Google

tikararẹ̀, nisisiyi lati wá si iwaju Ọlọrun fu wa: kì sì iṣe pe ki o le ma fi ara rẹ̀ rubọ nigbakugba, bi olori alufa ti ima wọ̀ inu ibi mimọ́ lọ li ọdọdún ti on ti ẹ̀jẹ ẹlomiran; njẹ nitori bẹ̃ on kò le ṣalma ma jìya nigbakugba lati igba ipilẹ ọjọ ìwa: ṣugbọn nisisiyi li o fi ara hàn lẹ̃kan li opin aiye lati mu ẹ̀ṣẹ kuro nipa ẹbọ ara rẹ̀. Bi a sì ti pin-nu rẹ̀ fu enia pe lẹ̃kan li a kú, ṣugbọn lẹhin eyi ni idajọ: bẹ̃li a sì fi Kristi rubọ lẹ̃kan lati rù ẹ̀ṣẹ̀ ti ọpọlọpọ enia; ati fu awọn ti nwoye ọna rẹ̀ ni on yio sì farahàn nigba ekeji li aìli ẹ̀ṣẹ̀ si igbala.

Ihin-rere. Luku 22. 1.

IJỌ ọdún alwukara ti a npè ni Irekọja sì kùn fẹfẹ. Ati awọn olori alufa, ati awọn akọwe nwá ọna bi nwọn iba ti pa a; nitoriti nwọn mbẹ̀ru awọn enia. Nigbana ni Satan wọ̀ inu Juda lọ, ti a npè ni Iskariotu, ọkan ni ninu awọn mejejila. O sì mu ọna rẹ̀ pọ̀n, o lọ lati ba awọn olori alufa ati awọn olori ẹṣọ́ mọ̀ ọ pọ̀, bi on iba ti fi i hàn fu wọn. Nwọn sì yọ̀, nwọn ba a da majẹmu ati fu u li owo. O sì ba wọn ṣe adehùn, o sì nwá ọna ti yio fi fi i hàn fu wọn lẹhin ijọ awọn enia. Nigbana li ọjọ ti ijọ ọdún alwukara pé, nigbati nwọn o pa ẹran irekọja. O sì rán Peteru on Johanu, wipe, Ẹ lọ lati pèse irekọja fu wa, ki awa ki o jẹ. Nwọn sì bi i pe, Nibo ni iwọ nfẹ ki a pèse silẹ? O sì wi fu wọn pe, Kiyesi i, nigbati ẹnyin ba nwọ̀ ilu nla lọ, ọkọnri kan ti nrù ìṣa omi yio pade nyin; ẹ ma ba a lọ si ilekile ti o ba wọ̀. Ki ẹnyin ki o sì wi fu bãle ẹni rere na pe, Olukọni wi fu ọ pe, Nibo ni gbàngan apejẹ na gbé wà, nibiti emi o gbé jẹ irekọja pẹlu awọn ọmmọ ẹhin mi? On yio

Digitized by Google

sì fi gbàngan nla kan loke hàn nyin, ti a ṣe lọṣọ: nibè ni ki ẹnyin ki o pèse silẹ. Nigbati nwọn sì lọ, nwọn sì bá a gẹgẹ bi o ti sọ fu wọn: nwọn sì pèse irekọja silẹ. Nigbati o sì di akokò, o joko ati awọn aposteli mejejila pẹlu rẹ. O sì wi fu wọn pe, Tinu-tinu li emi nfẹ fi ba nyin jẹ irekọja yi, ki emi ki o to jìya: Nitori mo wi fu nyin, Emi kì yio jẹ ninu rẹ mọ́, titi a o fi pari rẹ ni ijọba Ọlọrun. Nigbati o sì mu ago, o sure, o ni, Gbà eyi, ki ẹnyin ki o sì pín i fu ara nyin. Nitori mo wi fu nyin, Emi kì yio mu ninu eso ajara mọ́, titi ijọba Ọlọrun yio fi de. Nigbati o sì mu akara, o sure, o sì bu u, o sì fifu wọn, o wipe, Ara mi ti a fifu nyin li eyi: ki ẹnyin ki o ma ṣe eyi ni iranti mi. Bẹ̃ gẹgẹ pẹlu ago lẹhin onjẹ alẹ, o wipe, Ago yi ni majẹmu titun li ẹ̀jẹ mi, ti a ta silẹ fu nyin. Ṣugbọn ki ẹnyin ki o kiyesi i, ọwọ́ ẹniti o fi mi hàn o pẹlu mi lori tabeli. Ati lõtọ Ọmmọ ọkọnri nlọ bi a ti pin-nu rẹ: ṣugbọn egbé ni fu ọkọnri na lodọ ẹniti a gbé ti fi i hàn! Nwọn sì bẹrẹ si ibère ninu ara wọn, li ẹniti ṣe ninu wọn, ti o jẹ ṣe nkan yi. Ijà kan sì mbẹ ninu wọn, li ẹniti yio ṣe olori ninu wọn. O sì wi fu wọn pe, Awọn ọba Keferi a ma lò ipá oluwa si wọn; a sì ma pè awọn ti nlò ipá ọllá si wọn ni olõre. Ṣugbọn ẹnyin kì yio sì ri bẹ̃: bikoṣe ẹniti o pọ̀ju lọ ninu nyin ki o jẹ bi aburo; ati ẹniti o sì ṣe ọlọllá, ki o ṣe bi iranṣẹ. Njẹ tali o pọ̀ju, ẹniti o joko tì onjẹ, tabi ẹniti o nṣe iranṣẹ? ẹniti o joko tì onjẹ kọ́? ṣugbọn emi mbẹ ninu nyin bi ẹniti nṣe iranṣẹ. Ẹnyin li awọn ti o ti mba mi gbé ninu ipọnju mi. Mo sì yàn ijọba fu nyin, gẹgẹ bi Babba mi ti yàn ijọba fu mi; ki ẹnyin ki o le ma jẹ, ki ẹnyin ki o sì le ma mu lori tabeli mi ni ijọba

Digitized by Google

mi, ki ẹnyin ki o le joko lori itẹ́, ati ki ẹnyin ki o le ma ṣe idajọ fu awọn ẹ̀ya Israeli mejejila. Oluwa sì wipe, Simon, Simon, sawò o, Satan nfẹ́ nyin lati ni, ki o le kù nyin bi elubó alikama: ṣugbọn mo ti gbadura fu o, ki igbagbó rẹ ki o má yẹ̀: nigbati iwọ ba sì yipada, mu awọn arakọnri rẹ li ọkkàn le. O sì wi fu u pe, Oluwa, mo mura tan lati bá ọ lọ sinu tubu, ati si ikú. O sì wipe, Mo wi fu ọ, Peteru, akukọ kì yio kọ loni, ti iwọ o fi sẹ́ mi li ẹrinmẹta pe, iwọ kò mọ̀ mi. O sì wi fu wọn pe, Nigbati mo rán nyin lọ laìni asuwọn, ati birigami, ati bàta, ọdá ohun kan da nyin bi? Nwọn sì wipe, Kurumu. Nigbana li o wi fu wọn pe, Ṣugbọn nisisiyi, ẹniti o ba li asuwọn, ki o mu u, ati birigami rẹ̀ pẹlu: ẹniti kò ba sì ni idà, ki o tà aṣọ rẹ̀, ki o sì fi rà kan. Nitori mo wi fu nyin pe, Eyi ti a ti kọwe rẹ̀ kò le ṣe ki o má ṣẹ lara mi, A sì kà a kún awọn arufin: nitori ohun wọn-ni nipa ti emi o li opin. Nwọn sì wipe, Oluwa, sawò o, idà meji mbẹ nihinyi, O sì wi fu wọn pe, o to. Nigbati o jade, o lọ bi iṣe rẹ̀, si òke Olifi; awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ sì tọ̀ ọ lẹhin lọ. Nigbati o wà nibẹ̀, o wi fu wọn pe, Ẹ ma gbadura, ki ẹnyin ki o máṣe bọ sinu idẹwò. O sì fi wọn silẹ̀ niwọn isọ̀ kan, o wolẹ̀ lori ẽkun rẹ̀, o sì ngbadura, wipe, Babba, bi iwọ ba fẹ́, gbà ago yi lọwọ́ mi: ṣugbọn ifẹ ti emi kọ́, bikoṣe ti rẹ̀ ni ki a ṣe. Angeli kan sì tọ̀ ọ lati ọrun wá, o ngbà a ni iyanju. Bi o sì ti wà ni iwaya-ija o ngbadura si i kikankikan: õgùn rẹ̀ dabi iro ẹ̀jẹ̀ nla, o nkán silẹ̀. Nigbati o sì dide kuro ni ibi adura, ti o sì tọ̀ awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ wá, o ba wọn, nwọn nsùn fu ikãnu, O sì wi fu wọn pe, Kili ẹnyin nsùn si? ẹ dide, ẹ ma gbadura, ki ẹnyin ki o máṣe bọ

Digitized by Google

sinu idẹwò. Bi o sì ti nsọ lọwọ́, kiyesi i, ọpọ enia, ati ẹniti a npè ni Juda, ọkan ninu awọn mejejila na, o ṣaju wọn, o sumọ́ Jesu lati fi ẹnu kò o li ẹnu. Ṣugbọn Jesu sì wi fu u pe, Juda, iwọ fi ifẹnukonu fi Ọmmọ ọkọnri hàn? Nigbati awọn ti o wà lọdọ rẹ ri bi yio ti jasi, nwọn bi i pe, Oluwa, ki awa ki o fi idà ṣá wọn? Ọkan ninu wọn si fi idà ṣá iranṣẹ ti olori awọn alufa kan, o sì ke etí ọtún rẹ̀ sọnù. Jesu sì dahùn o wipe, Ẹ duro to bayi na. O sì fi ọwọ́ tọ́ ọ li etí, o sì mu u jiná. Nigbana ni Jesu wi fu awọn olori alufa, ati fu awọn olori ẹṣọ́ ti tempeli (ile Ọlọrun,) ati fu awọn alàgba, ẹniti o wá sọdọ rẹ̀ pe, Ẹnyin jade wá bi ẹnipe si olè, ti ẹnyin ti idà ati ọgọ? Nigbati emi fi wà pẹlu nyin ninu tempeli (ile Ọlọrun) ni ijọ gbogbo, ẹnyin kò nà ọwọ́ si mi lati mu: ṣugbọn akokò ti nyin li eyi, ati agbara òkunkun. Nigbana nwọn gbá a mu, nwọn sì fà a lọ, nwọn sì mu u wá si ile ti olori awọn alufa. Peteru sì ntọ́ ọ lẹhin li òkere. Nigbati nwọn sì ti dana larin gbàngan, bi nwọn sì ti joko pọ̀, Peteru wá o joko larin wọn. Nigbati o sì ṣe, ọmmọbiri kan wò o bi o ti joko letí iná, ti o sì tẹjumọ́ ọ, o ni, Ọkọnri yi sì wà pẹlu rẹ̀. O sì sẹ́ ẹ, o wipe, Obiri yi, emi kò mọ̀ ọ. O pẹ diẹ si, ẹlomiran sì tún ri i, o ni, Ati iwọ pẹlu wà ninu wọn. Peteru sì wipe, Ọkọnri yi, Emi kì iṣe. O sì di òsa wakati kan ọjọ lẹhin eyi, ẹlomiran sì tẹnumọ́ ọ, wipe, Nitõtọ eyiyi ma wà pẹlu rẹ̀: nitori ara Galili ni iṣe. Peteru sì wipe, Ọkọnri yi, emi kò mò eyi ti iwọ nwi. Lojukan na, bi o ti nwi li ẹnu, akukọ kọ. Bi Oluwa sì ti yipada, o wò Peteru. Peteru sì ranti ọrọ Oluwa, bi o ti wi fu u pe, Ki akukọ ki o to kọ, iwọ o sẹ́ mi li ẹrinmẹta.

Digitized by Google

Peteru sì bọ si ode o sọkun kikorò. Awọn ọkọnri ti nwọn sì mu Jesu, nwọn fi i sẹ ẹlẹyà, nwọn lù u. Nigbati nwọn sì dì i loju, nwọn lù u niwaju, nwọn mbi i pe, Sọ fu wa tẹlẹ, tani nlù iwọ ni? Ati nkan omiran pipọ ni nwọn nfi ọrọ òdi sọ si i. Nigbati ilẹ sì ti mọ, awọn alàgba enia, ati awọn olori alufa, ati awọn akọwe pejọ, nwọn sì fà a wá si ijọ wọn, nwọn nwipe, Iwọ ni Kristi na? sọ fu wa. O sì wi fu wọn pe, Bi mo wi fu nyin, ẹnyin kì yio gbagbọ: bi mo sì bi nyin lẽre pẹlu, ẹnyin kì yio da mi lohùn, bẽli ẹnyin kì yio jọwọ mi lọwọ lọ. Lẹhin eyiyi li (ẹnyin o ri) Ọmmọ ọkọnri yio joko li ọwọ ọtún ti agbara Olọrun. Gbogbo wọn sì wipe, Iwọ ha sẹ Ọmmọ Olọrun bi? O sì wi fu wọn pe, Ẹnyin wi pe emi ni. Nwọn sì wipe, Kili awa nwá ẹlẽri kiri mọ si? Awa tikara wa sá ti gbọ li ẹnu ara rẹ.

THURSDAY TI O ṢAJU (EASTER) AJINDE.

Episteli. 1 Kor. 11. 17.

NJẸ emi kò yìn nyin nitori eyiti emi nfi aṣẹ fu nyin nisisiyi pe, ẹnyin pejọ pọ kì iṣe fu rere, ṣugbọn fu buburu nyin. Nitori ṣaju ohun gbogbo mo gbọ pe, nigbati ẹnyin pejọ ni ile Olọrun, ìyapa mbẹ ninu nyin; mo sì gbà a gbọ li apakan. Nitoripe kò le ṣe ki o má si awọn aladamọ ninu nyin pẹlu, ki awọn ti iṣe ẹni itẹwọgbà ba le fi ara hàn. Nitorina nigbati ẹnyin ba pejọ pọ si ibi kan, eyi kì iṣe lati jẹ Onjẹ Alẹ Oluwa. Nitoripe ni jijẹ ẹnikan ngbà onjẹ ti rẹ ṣaju ẹnikeji: ebi npa ẹnikan, ẹnikeji sì nmu amupara. Kinla? ẹnyin kò ni ile, nibiti ẹnyin o ma jẹ ti ẹnyin o ma mu? tabi ẹnyin ngàn ijọ awọn

Digitized by Google

enia Ọlọrun, ẹnyin sì ndojutì awọn ti kò ni? Kili emi o wi fu nyin? emi o ha yìn nyin ninu eyi? emi kò yìn nyin rara. Nitoripe lọwọ Oluwa ni mo ti gbà eyini ti mo ti fifu nyin pẹlu, Pe Jesu Oluwa li oru ọjọ na ti a ṣofofo rẹ̀ o mu akara: nigbati o sì dupẹ, o bù u, o sì wipe, Gbà, jẹ: eyiyi li ara mi ti a gbọgbẹ fu nyin: ẹ ma ṣe eyi ni iranti mi. Gẹgẹ bẽ pẹlu li o sì mu ago, lẹhin igbati o jẹun tan, o nwipe, Ago yi ni majẹmu titun li ẹ̀jẹ mi: nigbakugba ti ẹnyin ba nmu u, ẹ ma ṣe eyi ni iranti mi. Nitori nigbakugba ti ẹnyin ba njẹ akara yi, ti ẹnyin ba sì nmu ago yi, ẹnyin nfi ikú Oluwa hàn titi yio fi de. Nitorina ẹnikẹni ti o ba jẹ akara yi, ti o sì mu ago ti Oluwa yi laiyẹ, on yio jẹbi ara ati ẹ̀jẹ ti Oluwa. Ṣugbọn je ki enia ki o wadi ara rẹ̀ daju, bẽni ki o jẹ ninu akara na, ki o sì mu ninu ago na. Nitoriti ẹnikẹni ti o ba njẹ, ti o ba sì nmu laiyẹ, o njẹ, o sì nmu ẹbi fu ara rẹ̀, kò sì mọ ara Oluwa. Nitori idi eyi li ọpọlọpọ fi di alailera ati olokunrun ninu nyin, ti ọpọlọpọ sì sùn. Nitoripe bi awa ba jẹ da ara wa lẹjọ, a kì yio sì da wa lẹjọ. Ṣugbọn nigbati a ba nda wa lẹjọ, lati ọwọ Oluwa li a ti n-nà wa, ki a máṣe da wa lẹbi pẹlu araiye. Nitorina, arakọnri mi, nigbati ẹnyin ba pejọ lati jẹun, ẹ ma duro dè ara nyin. Bi ebi ba sì npa ẹnikẹni, ki o jẹun ni ile rẹ̀; ki ẹnyin ki o máṣe pejọ fu ẹbi ara nyin. Iyokun li emi o tò lẹsẹsẹ nigbati mo ba de.

Ihin-rere. Luku 23. 1,

GBOGBO ijọ awọn enia sì dide, nwọn fà a lọ si ọdọ Pilatu. Nwọn sì bẹ̀rẹ si ifi i sùn, wipe, Awa ri ọkọnri yi o nyi awọn ẹnia

Digitized by Google

li okkàn pada, o sì nda wọn lẹkun lati san owode fu Kesari, o nwìpe on Kristi tikara on ọbba li on. Pilatu sì bi i lẽre, wipe, Iwọ li ọbba ti awọn Ju? O sì da a lohùn wipe, Iwọ wi i. Pilatu sì wi fu awọn olori alufa ati fu awọn enia pe, Emi kò ri èṣẹ lara ọkọnri yi. Nwọn sì gboju si i pe, O nrulu, o nkọ́ni ká gbogbo ilẹ ti awọn Ju, o bẹrẹ lati Galili wá titi o fi de ihinyi. Nigbati Pilatu ti gbọ́ orukọ Galili, o bère bi ọkọnri na ṣe ara Galili. Nigbati o sì mọ̀ pe ara ilẹ Herodu ni, o rán a si Herodu, ẹniti on tikararẹ̀ wà ni Jerusalemu li akokò na. Nigbati Herodu sì ri Jesu, o yọ̀ gidigidi: nitoriti o ti nfẹ ẹ ri pẹ, nitoriti o sì ti ngbọ́ ihin pipọ nitori rẹ̀; o sì tamã ati ri ki iṣẹ aṣẹ diẹ ki o ti ọwọ́ rẹ̀ ṣe. O sì bère ọ̀rọ pipọ lọwọ́ rẹ̀; ṣugbọn kò da a lohùn kanṣoṣo. Ati awọn olori alufa ati awọn akọwe duro, nwọn sì nfi i sùn gidigidi. Ati Herodu ti on ti awọn ọmmọ ogun rẹ̀, nwọn yà a si apakan, nwọn sì nfi i ṣẹṣin, nwọn wọ̀ ọ li aṣọ igunwà, o sì rán a pada tọ̀ Pilatu lọ. Pilatu on Herodu di ọrẹ́ ni ijọ na: nitori ọtá ara wọn ni nwọn nṣe ri nigba atijọ. Nigbati Pilatu sì ti pè awọn olori alufa ati awọn olori, ati awọn enia jọ, o sọ fu wọn pe, Ẹnyin mu ọkọnri yi tọ̀ mi wá, bi ẹni ti o npa awọn enia li ọkkàn da: sì kiyesi i, emi wadi ẹjọ rẹ̀ niwaju nyin, emi kò sì ri èṣẹ lara ọkọnri yi, ni gbogbo nkan wọnyi ti ẹnyin fi i sùn si: ati Herodu pẹlu: mo sá rán nyin tọ̀ ọ lọ; sì kiyesi i, ohun kan ti o yẹ si ikú a kò ṣe si i ti ọwọ́ rẹ̀ wá. Njẹ emi o nà a, emi a jọwọ́ rẹ̀ lọwọ́ lọ. Nitoriti iṣe ilu wọn, kò gbọdọ ṣe alda ọkan silẹ fu wọn nigba irekọja. Gbogbo wọn sì kigbe soke lọwọ́ kan na, wipe, Gbé ọkọnri yi kuro, ki iwọ ki o sì da Baraba silẹ

Digitized by Google

fu wa: ẹniti o ti itori ọtẹ ti a ṣe ni ilu nla, ati itori ipania, ti a sọ sinu tubu. Njẹ Pilatu nfẹ da Jesu silẹ, o sì tún sọ fu wọn. Ṣugbọn nwọn tún kigbe, wipe, Kàn a mọ́ agbelebu, kàn a mọ́ agbelebu. O sì tún bi wọn lẽre li ẹrinkẹta pe, Ere idi rẹ̀, buburu kili o ṣe? emi kò ri ọ̀ran ikú lara rẹ̀: nitorina emi o nà a, emi a sì jọwọ rẹ̀ lọwọ́ lọ. Nwọn tilẹ̀ kìrimọ́ igbe nla, nwọn nfẹ ki a kàn a mọ́ agbelebu. Ohùn ti wọn ati ti awọn olori alufa bori ti rẹ̀. Pilatu sì fi aṣẹ fu wọn pe, ki o ri bi nwọn ti nfẹ. O sì da ẹniti a ti itori ọtẹ ati ipania sọ sinu tubu silẹ fu wọn, ẹniti nwọn nfẹ; bẽli o sì fi Jesu fu ifẹ wọn. Bi nwọn sì ti nfà a lọ, nwọn mu ọkọnri kan, Simon ara Kirene, ti o nti igberiko ibọ̀, on ni nwọn sì gbé agbelebu le, ki o ma rù u wá lẹhin Jesu. Ijọ awọn enia pipọ li o ntọ̀ ọ lẹhin, ati awọn obiri pẹlu, ti nwọn sì npohùnrere ẹkún, ti nwọn sì nṣe idarò rẹ̀. Ṣugbọn Jesu, o yiju pada si wọn, o wipe, Ẹnyin ọmmọbiri Jerusalemu, ẹ má ṣokun fu mi, ṣugbọn ẹ sọkun fu ara nyin, ati fu awọn ọmmọ nyin. Nitori kiyesi i, ọjọ mbọ̀ li eyiti ẹnyin o wipe, Ibukún ni fu àgan, ati fu inu ti kò bímọ ri, ati fu ọmú ti kò fu ni mu ri. Nigbana ni nwọn o bẹ̀rẹ si iwi fu òke nla pe, Wó lu wa; ati fu òke kekere pe, Bò wa mọlẹ. Nitori bi nwọn nṣe nkan wọnyi lara igi tutù, kili a o ṣe ni ti gbigbẹ? Nwọn sì nmu awọn omiran, arufin meji, lọ lati pa pẹlu rẹ̀. Nigbati nwọn de ibi, ti a npè ni Ibi agbari, nibẹ̀ ni nwọn gbé kàn a mọ́ agbelebu, ati awọn arufin na, ọkan li ọwọ́ ọtún ati ekeji li ọwọ́ òsi. Nigbana ni Jesu wipe, Babba, darijì wọn; nitoriti nwọn kò mọ̀ ohun ti nwọn nṣe. Nwọn sì pín aṣọ rẹ̀, nwọn ndi ìbo rẹ̀. Awọn enia sì duro

Digitized by Google

nworan. Ati awọn ijoye pẹlu wọn, nwọn nyọ-sùti si i, wipe, O gbà awọn ẹlomiran là; ki o gbà ara rẹ̀ là, bi iba ṣe Kristi, ayanfẹ Ọlọrun. Ati awọn ọmmọ ogun pẹlu nfi i ṣe ẹlẹyà, nwọn ntọ́ ọ wá, nwọn nfi ọti kikan fu u, nwọn sì nwipe, Bi iwọ iba ṣe Ọbba ti awọn Ju, gbà ara rẹ là. Nwọn sì kọwe akọle si igberi rẹ̀ ni èdè ti Helene, ati ti Latin, ati ti Heberu, EYIYI LI ỌBBA TI AWỌN JU. Ati ọkan ninu awọn arufin ti a kàn mọ́ agbelebu pẹlu rẹ̀ o nsọ ọ̀rọ buburu si i, wipe, Bi iwọ iba ṣe Kristi, gbà ara rẹ ati awa là. Eyi ekeji sì dahùn, o mba a wi pe, Iwọ kò bẹ̀ru Ọlọrun, ti iwọ wà ninu ẹbi na? Ati awa nitõtọ; nitori ère ti wa li awa njẹ: ṣugbọn ọkọnri yi kò ṣe nkan èṣi. O sì wi fu Jesu pe, Oluwa, ranti mi nigbati iwọ ba de ijọbba rẹ. Jesu sì wi fu u pe, Lõtọ ni mo wi fu ọ, Loni ni iwọ o wà pẹlu mi ni Paradise. O sì to ìwọn wakati ẹkẹfa ọjọ́, òkunkun sì ṣú bò gbogbo ilẹ titi o fi di wakati ẹkẹsan ọjọ́. Õrùn sì ṣú òkunkun, aṣọ ikele ti tempeli (ile Ọlọrun) sì ya li agbedemeji. Nigbati Jesu sì kigbe li ohùn rara, o ni, Babba, li ọwọ́ rẹ ni mo fi ẹmí mi le: nigbati o sì wi bẽ, o jọwọ ẹmmí rẹ̀ lọwọ́. Nigbati ibalogun ọrún ri ohun ti o ṣe, o yìn Ọlọrun logo, wipe, O daniloju gbangba olododo li ọkọnri yi. Ati gbogbo awọn enia ti o pejọ si iran na, nwọn nwò ohun ti nṣe, nigbati nwọn ba lù ara wọn li õkan àiya, nwọn a pada. Ati gbogbo awọn ojulumọ́ rẹ̀, ati awọn obiri ti ntọ́ ọ lẹhin lati Galili wá, nwọn duro li òkere, nwọn nwò nkan wọnyi.

Digitized by Google

ỌJỌ TI ÌJIYA ATI IKÚ JESU KRISTI TI A NPÈ NI

FRIDAY RERE.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, li oju-rere ki iwọ ki o wò awọn ara ile rẹ yi, nitori eyi ti Jesu Kristi Oluwa wa kò rahùn ni ti aṣofofo rẹ̀, ati ti a fi i le ọwọ́ awọn enia buburu, ati lati jìya ikú lori agbelebu, ẹniti o wà nisisiyi ti o sì njọbba pẹlu iwọ ati Ẹmmí Mimọ́, lai Olọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

OLODUMARE ati aiye-raiye Olọrun, nipa Ẹmmí ẹniti a nṣe akoso, ti a sì nsọ gbogbo Ijọ awọn enia Olọrun di mimọ́; Gbà ẹbẹ ti awa mbẹ̀, ati adura ti awa ngbà siwaju rẹ, fu ìwa gbogbo ti awọn enia ninu Ijọ awọn enia mimọ́, ki olukuluku ẹniti ṣe ara inu rẹ̀ na, ninu ìpe ati iṣẹ́ alufa rẹ̀, ki o ma sìn ọ nitõtọ ati ni ìwa-bi-Olọrun; nitori Jesu Kristi Oluwa ati Olugbala wa. *Amin.*

OLỌRUN alãnu, iwọ ti o ti da gbogbo awọn enia, ti iwọ kò sì korira ohun-kohun ti iwọ da, bẹ̃ni iwọ kò fẹ ikú ẹlẹṣẹ, bikoṣe pe ki o kuku yipada ki o sì yè; Ṣãnu fu gbogbo awọn Ju, awọn Imale, awọn Keferi, ati awọn Aladamọ̀, ki iwọ ki ọ sì gbà aìmọ gbogbo, lile àiya, ati ẹ̀gan Ọrọ rẹ lọwọ́ wọn; bẹ̃ni ki iwọ ki o sì mu wọn bọwá ile, Oluwa olubukun, si agbo agutan rẹ, ki a le gbà wọn là pẹlu awọn enia Israeli tõtọ iyokù, ki a sì sọ wọn di agbo kan lọdọ olusọ agutan kan, Jesu Kristi Oluwa wa, ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu iwọ ati Ẹmmí Mimọ́, Olọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. Heb. 10. 1.

NITORIPE bi ofin ti ni ojiji ohun rere ti mbọ̀, ṣugbọn kì iṣe aworan ti nkan wọnni, pẹlu ẹbọ wọn-ni ti nwọn nru nigba-gbogbo li ọdọdún, kò le mu awọn ti nwá sibẹ̀ di pipé. Njẹ nitorina kì ba ti dẹkun lati ma ru wọn li ẹbọ? nitoripe awọn olùsin ti a ti wẹ̀numọ lẹ̀kan ki ba ti ni ìmọ ẹ̀ṣẹ mọ́. Ṣugbọn ninu ẹbọ wọn-ni a si tún nṣe iranti ẹ̀ṣẹ li ọdọdún. Nitori o ṣoro pe ki ẹ̀jẹ ti akọ malu ati ti ewurẹ, ti yio fi mu ẹ̀ṣẹ kuro. Nitorina nigbati o wá si aiye, o wipe, Ẹbọ ati ẹbọ ọrẹ iwọ kò fẹ, ṣugbọn ara ni iwọ ti pèse silẹ fu mi: niti ẹbọ ọrẹ sisọn ati ẹbọ nitori ẹ̀ṣẹ iwọ kò ni inu-didùn si. Nigbana ni mo wipe, Kiyesi i, Mo de lati ṣe ifẹ ti rẹ, Ọlọrun, (ninu àpo iwe ni li a gbé kọ ọ nipa ti emi.) Nitiṣaju nigbati o wipe, Ẹbọ, ati ẹbọ ọrẹ, ati ẹbọ ọrẹ sisọn, ati ẹbọ nitori ẹ̀ṣẹ ni iwọ kò fẹ, bẹ̀ni iwọ kò ni inu-didùn si i; ti a ti nru nipa ti ofin; nigbana ni o wipe, Kiyesi i, Mo de lati ṣe ifẹ ti rẹ, Ọlọrun. O mu ti iṣaju kuro, ki o le fi idi ekeji mulẹ. Nipa ifẹ yi na li a nsọ wa di mimọ́ nipa ifi ara Jesu Kristi tọrẹ lẹ̀kan ṣoṣo. Ati olukuluku alufa ti nduro li ojojumọ́ ti nṣe lsin, ti o sì nṣe ẹbọ kan na nigba-kugba, ti kò le mu ẹ̀ṣẹ kuro lai: ṣugbọn ọkọnri yi, lẹhin igbati o ti ru ẹbọ kan fu ẹ̀ṣẹ titi lai, o joko li ọwọ́ ọtún Ọlọrun; lati isisiyi lọ, o nreti titi a o fi fi awọn ọtá rẹ̀ ṣe apoti itisẹ rẹ̀. Nitoripe nipa ẹbọ kan o sì ti mu awọn ti a sọdi mimọ́ pé titi lai. Ẹmmí Mimọ́ sì li ẹlẹ̀ri fu wa pẹlu: nitori lẹhin igbati o ti wi ṣaju pe, Eyi ni majẹmu ti emi yio ba wọn da lẹhin ọjọ wọn-ni, Oluwa wipe, emi o fi ofin mi si wọn li àiya, ati ni inu wọn li emi o kọ wọn si; ati awọn ẹ̀ṣẹ wọn ati

Digitized by Google

alṣedede wọn li emi kì yio sì ranti mọ́. Ṣugbọn nibiti imu kuro nkan wọnyi ba gbé wà, irubọ nitori èṣẹ̀ kò sì mọ́. Arakọnri, njẹ bi a ti n-ni igboiya lati wọ inu ibi mimọ́ julọ nipaṣẹ ẹjẹ ti Jesu, nipa ọna titun ati alãye, ti o ti yà si mimọ́ fu wa, nipaṣẹ aṣọ ikele ni, eyini ni pe, ara rẹ̀; ati pe ti a n-ni olori alufa kan lori ile Ọlọrun; ẹ jẹ ki a fi otitọ àiya sumọ́ tosi pẹlu idaniloju ti o kún fu igbagbọ́ ki a sì fi ibuwọ́n wẹ̀ inu buburu ọkkàn wa nù, ki a sì fi omi mimọ́ wẹ̀ ara wa nù. Ẹ jẹ ki a dì ijẹwọ ti ireti wa mu li alṣiyemeji; (nitoripe olõtọ li ẹniti o ṣe ileri;) ẹ jẹ ki a sì gbà ara wa rò lati gbà niyanju si ifẹ́ ati si iṣẹ rere: ni alkọ ipejọ pọ̀ ara wa silẹ, gẹgẹ bi ìwa ti awọn ẹlomiran ti ri; ṣugbọn bikoṣe ki a ma gbà ara ẹni niyanju: tobẽ melomelo sì ni, bi ẹnyin ti ri ti ọjọ nsumọ́ etile.

Ihin-rere. Joh. 19. 1.

NITORINA Pilatu mu Jesu, o sì nà a. Awọn ọmmọ ogun sì wún ade ẹgún, nwọn sì fi de e li ori, nwọn sì fi aṣọ igunwà elesè àluko wọ̀ ọ, nwọn sì wipe, Alafia, Ọbba ti awọn Ju! nwọn sì fi ọwọ́ wọn gbá a loju. Nitorina Pilatu tún jade, o sì wi fu wọn pe, Kiyesi i, mo mu u jade tọ̀ nyin wá, ki ẹnyin ki o le mọ̀, pe, emi kò ri èṣẹ̀ kan lọwọ́ rẹ̀. Nigbana ni Jesu jade wá, ti on ti ade ẹgún ati aṣọ igunwà elesè àluko. Pilatu sì wi fu wọn pe, Ẹ wò ọkọnri na! Nitorina nigbati awọn olori alufa, ati awọn oniṣẹ ri i, nwọn kigbe soke wipe, Kàn a mọ́ agbelebu, kàn a mọ́ agbelebu. Pilatu wi fu wọn pe, Ẹ mu u, ki ẹ sì kàn a mọ́ agbelebu: nitoriti emi kò ri ohun èṣẹ̀ kan lọwọ́ rẹ̀. Awọn Ju da a lohùn

Digitized by Google

wipe, Awa lí ofin kan, ati nipa ofin wa o yę lati kú, nitoriti o fi ara rę ṣe Ọmọ Ọlọrun. Nitorina nigbati Pilatu gbọ́ ọ̀rọ̀ ni, o bẹ̀ru gidigidi; O sì tún wọ̀ inu gbàngan idajọ lọ, o sì wi fu Jesu pe, Nibo ni iwọ ti wá? Ṣugbọn Jesu kò da a lohùn. Nigbana ni Pilatu wi fu u pe, Iwọ kò fọhun si mi? iwọ kò mọ̀ pe, emi li agbara lati kàn ọ mọ́ agbelebu, emi sì li agbara lati da ọ silẹ? Jesu dahùn wipe, Iwọ kì ba ti li agbara kan lori mi, bikoṣepe a ti fi i fu ọ lati oke wá: nitorina ẹniti o fà mi le ọ lọwọ́ li o ni ẹ̀ṣẹ̀ pọ̀ju. Lati igba na lọ ni Pilatu sì ti nwá ọ̀na lati da a silẹ: ṣugbọn awọn Ju kigbe soke, wipe, Bi iwọ ba jọwọ ọkọnri yi lọwọ́ lọ, iwọ kì iṣe ọ̀rẹ́ Kesari: ẹnikẹni ti o ba fi ara rę ṣe ọba, on sọ̀rọ̀ òdi si Kesari. Nitorina nigbati Pilatu sì ti gbọ́ irú ọ̀rọ̀ ni, o mu Jesu jade wá, o sì joko lori itẹ́ idajọ nibikan ti a npè ni Titẹ̀okuta ni, ṣugbọn li ède Heberu, Gabata. O sì jẹ ọjọ́ ipalẹmọ́ ti ijọ irekọja, nigba wakati ẹkẹfa: o sì wi fu awọn Ju pe, Ẹ wò Ọba nyin! Ṣugbọn nwọn kigbe soke wipe, Mu u kuro, mu u kuro, kàn a mọ́ agbelebu. Pilatu wi fu wọn pe, Emi o ha kàn Ọba nyin mọ́ agbelebu bi? Awọn olori alufa dahùn wipe, Awa kò li ọba kan bikoṣe Kesari. Nigbana li o fà a le wọn lọwọ́ lati kàn a mọ́ agbelebu. Nwọn sì mu Jesu, nwọn sì fà a jade. On sì nrù agbelebu rę lọ si ibi kan, ti a npè ni Ibi agbari, li ède Heberu ti a npè ni Golgota: nibi ti nwọn gbé kàn a mọ́ agbelebu, ati awọn meji omiran pẹlu rẹ̀, ekini li apa kan, ati ekeji li apa ekeji, Jesu sì wà larin. Pilatu sì kọwe akọle kan, o fi le ori agbelebu na. Ikọwe na sì jẹ́, JESU TI NASARETI ỌBBA TI AWỌN JU. Ọpọlọpọ awọn Ju li

Digitized by Google

o kà ikọwe yi: nitori ibi ti a gbé kàn Jesu mọ́ agbelebu sumọ́ etí ilu nla: a sì kọ ọ li ède Heberu, ati ni ti Helene, ati ni ti Latin. Nigbana li awọn olori alufa ti awọn Ju wi fu Pilatu pe, Máṣe kọ ọ pe, Ọbba ti awọn Ju; ṣugbọn pe on li o wipe, Emi li Ọbba ti awọn Ju. Pilatu dahùn wipe, Ohun ti mo ti kọ tan, mo ti kọ tan. Nigbana li awọn ọmmọ ogun, nigbati nwọn kàn Jesu mọ́ agbelebu tan, nwọn mu aṣọ rẹ̀, nwọn sì pín wọn si ipa mẹrin, apakan fu ọmmọ ogun ọkọkan; ati ẹwu rẹ̀ pẹlu: njẹ nisisiyi ẹwu na kò li ojuran, nwọn wún ọ lati oke titi jalẹ. Nitorina nwọn wi fu ara wọn pe, Jẹ ki awa máṣe fà a ya, ṣugbọn ki a ṣẹ gege nitori rẹ̀, ti ẹniti yio jẹ: ki Iwe mimọ́ Ọlọrun ki o le ṣẹ, ti o wipe, Nwọn pín aṣọ mi fu ara wọn, nwọn sì ṣẹ gege fu aṣọ ileke mi. Nkan wọnyi li awọn ọmmọ ogun ṣe. Awọn ẹnikan sì duro nibi agbelebu Jesu, iya rẹ̀, ati arabiri iya rẹ̀, Maria aya Kleofa, ati Maria Magdalene. Nitorina nigbati Jesu ri iya rẹ̀, ati ọmmọ ẹhin na sì duro, ẹniti Jesu fẹ, o wi fu iya rẹ̀ pe, Obiri, wò ọmmọkọnri rẹ̀! Nigbana li o sì wi fu ọmmọ ẹhin na pe, Wò iya rẹ̀! Lati wakati na lọ li ọmmọ ẹhin na sì ti mu u lọ si ile ara rẹ̀. Lẹhin eyi, bi Jesu ti mọ́ pe, a sì ti pari ohun gbogbo tan, ki Iwe mimọ́ Ọlọrun ki o le ba ṣẹ, o wipe, ọrọngbẹ ngbẹ mi. A sì gbé ohun èlo kan kalẹ nibẹ̀ nigbana ti o kún fu ọti kikan: nwọn sì tẹ spunge bọ inu ọti kikan, nwọn fi i le ori ọpá hisopu, nwọn sì fi i si i lẹnu. Nitorina nigbati Jesu sì ti gbà ọti kikan na, o wipe, O pari: o sì tẹ ori rẹ̀ ba, o jọwọ ẹmmí rẹ̀ lọwọ́. Nigbana li awọn Ju bẹ̀ Pilatu pe, ki a le ṣẹ́ egungun itan wọn, ati ki a le gbé wọn kuro, nitoriti iṣe ipalẹmọ́, ki

Digitized by Google

okú wọn ki o máṣe wà lori agbelebu li ọjọ isimi, nitori ọjọ nla ni ọjọ isimi ni. Nigbana li awọn ọmmọ ogun de, nwọn sì ṣẹ́ egungun itan ti ekini, ati ti ekeji, ti a kàn mọ́ agbelebu pẹlu rẹ̀. Ṣugbọn nigbati nwọn de ọdọ Jesu, ti nwọn sì ri pe, o ti kú tan, nwọn kò sì ṣẹ́ egungun itan rẹ̀: ṣugbọn ọkan ninu awọn ọmmọ ogun na fi ọ̀kọ gún u li ẹgbẹ, lojukan na ẹ̀jẹ ati omi sì tú jade. Ẹniti o ri i sì jẹ́ri, otitọ sì li ẹ̀rí rẹ̀: o sì mọ̀ pe õtọ li on wi, ki ẹnyin ki o le gbagbọ́. Nitori a se nkan wọnyi, ki Iwe mimọ Ọlọrun ki o le ṣẹ, ti o wipe, A kì yio fọ́ egungun rẹ̀. Iwe mimọ́ Ọlọrun omiran ẹ̀wẹ sì wipe, Nwọn o ma wò ẹniti a gún li ọ̀kọ.

AṢALẸ TI O ṢAJU ỌJỌ AJINDE.

Adura.

OLUWA, fifu wa, pe bi a ti baptisi wa sinu ikú Jesu Kristi Olugbala wa Ọmmọ rẹ olubukún, bẹ̃ni nipa pipọn ifẹ́ bibajẹ wa loju titi lọ, ki a le sin wa pẹlu rẹ̀; ati pe nipa isà okú ati ẹnu ọna ikú, ki awa ki o le kọja si ajinde wa ti o kún fu ayọ̀; nitori itoye rẹ̀, ẹniti o kú, ti a sì sin, ti o sì tún jinde fu wa, Ọmmọ rẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Pet. 3. 17.

OSÁ dara, bi ifẹ́ Ọlọrun ba ri bẹ̃, ki ẹnyin ki o jìya ni rere iṣe, jù ni buburu iṣe lọ. Nitori ti Kristi pẹlu o jìya lẹ̃kan nitori ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ fu awọn alaìṣõtọ, ki o le mu wa de ọdọ Ọlọrun, ẹniti a pa ni ikú ara, ṣugbọn ẹniti a ṣọ di ãye nipa Ẹmmí: nipa eyi ti o sì fi lọ ti o sì wasu fu awọn ẹmmí ti mbẹ ninu

Digitized by Google

tubu; nigbakan awọn ẹniti o ṣe alaìgbọran, ni sã kan ti lakari Ọlọrun duro pẹ titi nigba ọjọ Noa, nigbati nwọn fi nkàn ọkọ (arki) lọwọ́, ninu eyi ti enia diẹ là, eyini ni, ọkkàn mẹjọ nipa omi. Irú apẹrẹ bẽ gẹgẹ ni baptismu sì fi ngbà wa là nisisiyi, kì iṣe ìwẹ ẽri ti ara nù, ṣugbọn bikoṣe idahùn okkàn rere sipa Ọlọrun, nipa ajinde Jesu Kristi: ẹniti o ti lọ si ọrun, ti o sì mbẹ li ọwọ́ ọtún Ọlọrun; ori ti awọn angeli ati ti awọn ọlọlá ati alagbara li a fi mbalẹ fu u.

Ihin-rere. Mat. 27. 57.

NIGBATI alẹ lẹ tan, ọkọnri kan ọlọrọ̀ ara Arimatea wá ibẹ, ti a npè ni Josefu, ẹniti on tikararẹ̀ ṣe ọmmọ ẹhin Jesu pẹlu: O tọ̀ Pilatu lọ, o sì tọrọ okú Jesu. Nigbana ni Pilatu fi aṣẹ lati fi okú na fu u. Nigbati Josefu sì ti gbé okú na, o sì fi aṣọ ọgbọ mimọ́ di i, O sì tẹ́ ẹ sinu ibojì titun ti on tikararẹ̀, eyi ti a wọ̀ ninu apata: o sì yi okuta nla di ẹnu ọ̀na ibojì na, o lo. Maria Magdalene sì wà nibẹ̀, ati Maria ekeji, nwọn joko li apa etí ibojì na. Nigbati o di ọjọ ekeji, eyi ti o tẹ̀le ọjọ ipalẹmọ, awọn olori alufa, ati awọn Farisi wá pejọ lọdọ Pilatu, nwọn wipe, Alàgba, awa ranti pe ẹlẹtan ni wi, nigbati o ti wà lãye pe, Lẹhin ijọ mẹta, emi o tún jinde. Nitorina paṣẹ ki a kiyesi ibojì na daju titi yio fi di ọjọ ẹkẹta, ki awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ ki o máṣe wá li oru, nwọn sì nji i gbé lọ, ki nwọn ki o ma sì wi fu awọn enia pe, O jinde kuro ninu okú: bẽni ikẹhin lṣina yio buru jù ti iṣaju. Pilatu wi fu wọn pe, Ẹnyin li oluṣọ: ẹ lọ, ki ẹ kiyesi ibojì na daju bi ẹnyin ti fẹ. Bẽni nwọn lọ, nwọn sì nkiyesi ibojì na daju, nwọn sàmi di okuta na, nwọn sì nyàn iṣọ kan.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN TI AJINDE.

Orin mimọ.

ATI kàn Kristi irekọja wa mọ́ agbelebu fu wa: nitori na ẹ jẹ ki a ṣe ajọ na;

Kì iṣe pẹlu iwukara atijọ, bẹ̃ni kì iṣe pẹlu iwukara arankan ati ìwa buburu: bikoṣe pẹlu alwukara inu-funfun ati otitọ. 1 *Kor.* 5. 7.

BI Kristi ti jinde kuro ninu okú, on kò kú mọ́: ikú kò li agbara lori rẹ̀ mọ́.

Nitori ti o ti kú, o kú si ẹ̀ṣẹ̀ lẹ̃kan: ṣugbọn niti ti o wà lãye, o wà lãye si Ọlọrun.

Gẹgẹ bẹ̃ni ki ẹnyin ki o sì kà ara nyin pẹlu bi ẹniti o kú si ẹ̀ṣẹ̀ nitõtọ: ṣugbọn bi ẹniti o wà lãye si Ọlọrun nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Rom.* 6. 9.

KRISTI jinde kuro ninu okú: o sì di akọbi ninu awọn ti o sùn.

Nitori bi ikú ti ti ipa ọdọ enia wá: lati ipa ọdọ enia li ajinde okú ti wá pẹlu.

Nitori bi gbogbo enia ti nkú nipa ti Adamu: gẹgẹ bẹ̃ nipa ti Kristi gbogbo enia yio sì di alãye. 1 *Kor.* 15. 20.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí mimó;

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ̀ nisisiyi, bẹ̃ni yio sì ma ri nigba-gbogbo: aiye alnipẹkun. Amin.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, nipa Jesu Kristi Ọmmọ bíbi rẹ̀ nikanṣoṣo, ti iwọ ti ṣegun ikú, ti iwọ sì ti ṣí ilẹkun ìye ti kò nipẹkun silẹ fu wa; Awa nfi irẹlẹ ohùn bẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ̀, nitori pe, bi akanṣe ore-ọfẹ̀ rẹ̀ ti nṣaju wa, ti iwọ sì nfi ifẹ́ rere si wa ninu, nipa iranlọwọ

Digitized by Google

rẹ titi, bẽni ki a le ma mu eyi na wá si aṣẹ rere; nitori Jesu Kristi Oluwa wa, ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu iwọ ati Ẹmmí Mimọ́, lai Ọlọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Episteli. Kol. 3. 1.

NJẸ bi ẹnyin ba ti jinde pẹlu Kristi, ẹ ma ṣafẹri ohun ti mbẹ loke, nibiti Kristi gbé joko li ọwọ́ ọtún Ọlọrun. Ẹ ma gbé ifẹ́ ọkkàn nyin soke si ohun ti mbẹ li ọrun, kì iṣe si ohun ti mbẹ li aiye. Nitori ẹnyin ti kú, a sì fi ẹmmí nyin pamọ́ pẹlu Kristi ninu Ọlọrun. Nigbati Kristi, ẹniti iṣe ẹmmí wa, yio fi ara hàn, nigbana li ẹnyin pẹlu yio fi ara hàn pẹlu rẹ̀ ninu ogo. Nitorina ẹ ma pọ́n ẹ̀ya ara nyin ti mbẹ li aiye loju; àgbere, ìwa ẽri, ifẹkufẹ, ifẹ́ buburu, ati ojukòkoro, ti iṣe ibọrisa: nitori ohun ti ibinu Ọlọrun fi mbọ̀wa sori awọn ọmmọ alaìgbọran: ninu eyiti ẹnyin pẹlu ti nrìn nigba kan ri, nigbati ẹnyin ti wà ninu wọn.

Ihin-rere. Joh. 20. 1.

LI ọjọ ekini ọsẹ ni kutukutu nigbati ilẹ kò ti imọ́, ni Maria Magdalene wá si ibi ibojì, o sì ri pe, a ti gbé okuta kuro li ẹnu ibojì. Nigbana li o sare, o sì tọ̀ Simon Peteru wá, ati ọmmọ ẹhin omiran, ẹniti Jesu fẹ, o sì wi fu wọn pe, Nwọn ti gbé Oluwa kuro ninu ibojì, awa kò sì mọ̀ ibi ti nwọn gbé tẹ́ ẹ si. Nigbana ni Peteru lọ, ati ọmmọ ẹhin omiran na, nwọn sì wá si ibi ibojì. Bẽli awọn mejeji jùmọ nsare pọ̀: eyi ọmmọ ẹhin omiran ni sì sare yá Peteru kọja, o tetekọ de ibi ibojì. O bẹ̀rẹ, nigbati o wò inu ibojì, o ri aṣọ ọgbọ na lelẹ; ṣugbọn on kò wọ̀ inu rẹ̀. Nigbana ni Simon Peteru ẹniti ntọ̀ ọ lẹhin de,

Digitized by Google

o wọ̀ inu ibojì, o sì ri aṣọ ọgbọ̀ na lelẹ, ati gèle, ti o wà niha ori rẹ̀, kò sì wà pẹlu aṣọ ọgbọ̀ na, ṣugbọn a sì ká a jọ̀ li apakan fu ara rẹ̀. Nigbana li ọmmọ̀ ẹhin ekeji na, ẹniti o tètekọ̀ de ibojì wọ̀ inu rẹ̀ pẹlu, o ri, o sì gbagbọ́. Nitoripe titi fi di isisiyi, nwọn kò sá ti imọ̀ Iwe mimọ́ Ọlọrun pe, on kò le ṣalma jinde kuro ninu okú. Nigbana li awọn ọmmọ̀ ẹhin na sì pada lọ̀ sinu ile wọn.

MONDAY NI ỌṢẸ AJINDE.

Episteli. Iṣe 10. 34.

NIGBANA ni Peteru yà ẹnu rẹ̀, o ni, Nitõtọ̀ mo woye pe, Ọlọrun kì iṣe ojusaju enia: ṣugbọn ninu gbogbo orilẹ̀ èdè, ẹniti o ba bẹ̀ru rẹ̀, ti o sì ṣe otitọ̀, gbigbà ni lọdọ̀ rẹ̀. Ọrọ̀ ti Ọlọrun rán si awọn ọmmọ̀ Israeli, ti nwasu alafia nipa Jesu Kristi: (on li Oluwa ohun gbogbo:) ọ̀rọ̀ na ẹnyin mọ̀, ti a ti wasu yiká gbogbo Judea, ti a bẹ̀rẹ̀ si lati Galili wá, lẹhin baptismu ti Johanu wasu; bi Ọlọrun ti dà Ẹmmí Mimọ́ ati ọlá si Jesu ti Nasareti lori: ẹniti o nkiri lati ṣe ore, ati lati ṣe dida ara gbogbo awọn ti ara kan fu èṣu; nitoriti Ọlọrun wà pẹlu rẹ̀. Awa sì li ẹlẽri gbogbo ohun ti o ṣe, ati ni ilẹ̀ ti awọn Ju, ati ni Jerusalemu; ẹniti nwọn pa, ti nwọn sì fi há lori igi: on li Ọlọrun jinde ni ijọ̀ ẹkẹta, o sì fi i hàn nigbangba; kò ṣepe fu gbogbo enia, bikoṣe fu awọn ẹlẽri ti a ti yàn tẹlẹ̀ lati ọdọ̀ Ọlọrun wá, fu awa, ti awa ba a jẹ̀, ti awa sì ba a mu lẹhin igbati o jinde kuro ninu okú. O sì rán wa lọ̀ lati wasu fu awọn enia na, ati lati jẽri pe, on li a yàn lati ọdọ̀ Ọlọrun ṣe Onidajọ̀ ãye on okú.

Digitized by Google

On ni gbogbo awọn woli jẽ̀ri fu pe, ẹnikẹni ti o ba gbagbọ́ li orukọ rẹ̀, yio ri imukuro ẹ̀ṣẹ̀ gbà.

Ihin-rere. Luke 24. 13.

SÌ kiyesi i, awọn meji ninu wọn nlọ ni ijọ na si iletò kan ti a npè ni Emau, ti o jina si Jerusalemu niwọn ọgọta stadia. Nwọn mba ara wọn sọ̀rọ gbogbo nkan wọnyi ti o ṣe aṣe le ara wọn wọnyi. O sì ṣe, nigbati nwọn mba ara wọn sọ, ti nwọn sì mba ara wọn rò, Jesu tikararẹ̀ sì sumọ́ wọn, o sì mba wọn rìn lọ. Ṣugbọn a ru wọn li oju ki nwọn ki o máṣe le mọ̀ ọ. O sì bi wọn pe, Ọ̀rọ kili ẹnyin mba ara nyin sọ, bi ẹnyin ti nrìn, ti ẹnyin sì fajuro? Ọkan ninu wọn, ti a npè ni Kleopa, sì dahùn wi fu u pe, Alejò ṣá ni iwọ ni Jerusalemu, ti iwọ kò sì mọ̀ ohun ti o ṣe nibẹ̀ li ọjọ wọnyi? O sì bi wọn pe, Kini? Nwọn sì wi fu u pe, Niti Jesu ti Nasareti, ẹniti ṣe woli, ti o pọ̀ ni iṣẹ aṣẹ ati li ọ̀rọ niwaju Ọlọrun ati niwaju gbogbo awọn enia: ati bi awọn olori alufa ati awọn alàgba wa ti da a lẹbi si ikú, ati bi nwọn ti kàn a mọ́ agbelebu. Bẽni on li awa gbẹkẹle pe, on ni iba da Israeli ni ìde: pẹlupẹlu gbogbo nkan wọnyi oni li o di ijọ ẹkẹta ti nkan wọnyi ti ṣẹ̀. Awọn obiri kan pẹlu li ẹgbẹ wa, ti nwọn lọ si ibojì ni kutukutu, nwọn sì wá ida wa nijì; nigbati nwọn kò sì ri okú rẹ̀, nwọn wá wipe, awọn sì ri iran awọn angeli ti nwọn wipe, o wà lãye. Ati awọn kan ti nwọn wà pẹlu wa lọ si ibojì, nwọn sì ri i gẹgẹ bi awọn obiri ti wi: ṣugbọn on tikararẹ̀ ni nwọn kò ri. O sì wi fu wọn pe, Ẹniti oyé kò yé, ati ẹniti o yigbì li àiya lati gbà gbogbo eyi ti awọn woli ti wi gbọ́: kò yẹ ki Kristi ki o jìya nkan wọnyi, ki o sì wọ̀ inu ogo rẹ̀ lọ? O sì bẹ̀rẹ̀ lati Mose ati

Digitized by Google

gbogbo awọn woli wá, o sì tumọ̀ nkan fu wọn ninu Iwe mimọ́ Ọlọrun gbogbo nipa ti ara rẹ̀. Nwọn sì sumọ́ iletò ti nwọn nlọ: o sì ṣe bi ẹnipe yio lọ si iwaju. Nwọn sì rọ̀ ẹ, wipe, Ba wa duro: nitori o di ọjọ́ alẹ́, ọjọ́ sì kọja tan. O sì wọ̀le lọ o ba wọn duro. O sì ṣe, bi o ti ba wọn joko tì onjẹ́, o mu akara, o sure si i, o sì bù u, o sì fifu wọn. Oju wọn sì là, nwọn sì mọ̀ ẹ; o sì di ofo li oju wọn. Nwọn sì ba ara wọn sọ pe, Ọkkàn wa kò gbiná ninu wa, nigbati o mba wa sọ̀rọ̀ li ọ̀na, ati igbati ntumọ̀ Iwe mimọ́ Ọlọrun fu wa? Nwọn sì dide ni wakati na, nwọn pada lọ si Jerusalemu, nwọn sì ba awọn mọkọkanla pejọ, ati awọn ti mbẹ lọdọ wọn, nwipe, Oluwa jinde nitõtọ, o sì ti fi ara hàn fu Simon. Nwọn sì ròhin nkan ti o ṣe li ọ̀na, ati bi o ti di mimọ̀ fu wọn ni bibu akara.

TUESDAY NI ỌṢẸ AJINDE.

Episteli. Iṣe 13. 26.

ALÀGBA, arakọnri, awọn ọmmọ kukuté Abrahamu, ati ẹnikẹni ninu nyin ti o bẹ̀ru Ọlọrun, ẹnyin li a rán ọ̀rọ̀ igbala yi si. Nitori awọn ara Jerusalemu, ati awọn olori wọn, nitoriti nwọn kò mọ̀ eyi (Jesu,) ati ède ti awọn woli, ti a nkà li ọjọ́jọ́ isimi, kò yé wọn, nwọn mu wọn ṣẹ ni didajọ rẹ̀ lẹbi. Ati bi nwọn kò tilẹ̀ ti ri idi ohun ikú lara rẹ̀, ṣugbọn nwọn rọ̀ Pilatu lati pa a. Bi nwọn sì ti mu nkan gbogbo ṣẹ ti a ti kọwe tẹlẹ̀ nitori rẹ̀, nigbati nwọn sì sọ ọ kalẹ̀ kuro lori igi, nwọn sì tẹ́ ẹ si ibojì okuta. Ṣugbọn Ọlọrun jí i dide kuro ninu okú: a sì ri i li ọjọ́ pipọ ninu awọn ti o ba a gòke lati Galili wá si Jerusalemu, ẹniti nṣe ẹlẹ̃ri rẹ̀ fu awọn

Digitized by Google

enia. Awa sì nrò ihin ayọ fu nyin, bi ileri ti a ti ṣe fu awọn babba wa, bi Ọlọrun ti mu eyi na ṣẹ fu awa awọn ọmmọ wọn, ni ti o ti tún Jesu jí dide; bi a sì ti kọwe rẹ pẹlu ninu Psalmu ekeji pe, Iwọ li Ọmmọ mi, loni ni mo bí ọ. Bi o sì ṣepe ni ti o jí i dide kuro ninu okú, lati isisiyi lọ li alpada si ibajẹ mọ, o wi bayi pe, Emi o fu nyin ni ohun ore mimọ Dafidi, ti o daniloju. Nitorina o sì wi ninu Psalmu omiran pẹlu pe, Iwọ kì yio jẹ ki Ẹni Mimọ rẹ ki o di ibajẹ. Nitori lẹhin igba ti Dafidi sìn iran rẹ tan bi ifẹ Ọlọrun, o sùn, a sì tẹ ẹ lẹ awọn babba rẹ, o sì dibajẹ: ṣugbọn ẹniti Ọlọrun tún jinde kò dibajẹ. Njẹ ki o sì yé nyin, alàgba, arakọnri, pe nipasẹ ti ọkọnri yi li a nwasu idariji ẹṣẹ fu nyin: ati nipa ti rẹ li a ndare fu gbogbo awọn ti o gbagbọ ninu ohun gbogbo, ti a kò le da nyin lare nipa ofin Mose. Njẹ ki ẹnyin ki o kiyesi ara, ki eyini ki o máṣe de si nyin, ti a ti sọ ninu iwe awọn woli pe; Wò o, ẹnyin ẹlẹgàn, ki hà ki o ṣe nyin, ki ẹnyin ki o sì fò lọ: nitoriti mo ṣe iṣẹ li ọjọ nyin, iṣẹ ti ẹnyin kò jẹ gbagbọ bi enia tilẹ sọdi rẹ fu nyin.

Ihin-rere. Luke 24. 36.

JESU tikararẹ duro li arin wọn, o sì wi fu wọn pe, Alafia fu nyin. Ṣugbọn àiya fò wọn, nwọn sì dijì, nwọn ṣebi awọn ri iwin. O sì wi fu wọn pe, Eṣe ti ara nyin kò lelẹ? esitiṣe ti irokuro fi nsọ ninu ọkkàn nyin? Ẹ wò ọwọ mi ati ẹsẹ mi, pe emi tikarami ni: ẹ mu mi li ọwọ, ki ẹnyin ki o sì wò o; nitori ti iwin kò li ẹran on egungun lara, bi ẹnyin ti ri ti mo ni. Nigbati o sì wi bẽ tán, o fi ọwọ on ẹsẹ rẹ hàn wọn. Nigbati nwọn kò sì ti gbagbọ fu ayọ, ati fu hà ti nṣe wọn, o wi fu

Digitized by Google

wọn pe, Ẹnyin ni ohunkohun jijẹ nihinyi? Nwọn sì fu u li ẹja bibu, ati afára oyin diẹ. Nigbati o sì mu u, o jẹ loju wọn. O sì wi fu wọn pe Ọrọ wọnyi li emi ti nsọ fu nyin, nigbati emi ti wà pẹlu nyin pe, Kò le ṣe ki a má mu ohun gbogbo ṣẹ, ti ati kọ ninu ofin Mose, ati ninu iwe ti awọn woli, ati ninu Psalmu, nitori mi. Nigbana li o ṣí wọn ni iyè, ki Iwe mimọ Ọlọrun ki o le ma yé wọn, O sì wi fu wọn pe, Bẽli a kọwe rẹ, bẽli o sì yẹ ki Kristi ki o jìya, ati ki o sì jinde ni ijọ ẹkẹta kuro ninu okú: ati ki a wasu ironupiwada ati idariji ẹṣẹ li orukọ rẹ, li orilẹ ède gbogbo, bẹrẹ lati Jerusalemu lọ. Ẹnyin sì ni ẹlẽri nkan wọnyi.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKINI LẸHIN AJINDE.

Adura.

BABBA Olodumare, iwọ ti o fi Ọmmọ rẹ na kanṣoṣo funi, lati kú fu ẹṣẹ wa, ati lati tún jinde fu idalare wa; Fifu wa tobẽ lati fi iwukara arankan ati ìwa buburu silẹ, ki awa ki o le ma sìn ọ nigba-gbogbo ni mimọ ìwa ati ni otitọ; nitori itoye ti Ọmmọ rẹ na Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Joh. 5. 4.

ENIKẸNI ti a bí nipa ti Ọlọrun o ṣẹgun aiye: eyi sì ni iṣẹgun ti o ṣẹgun aiye, ani igbagbọ wa. Tani ẹniti o ṣẹgun aiye, bikoṣe ẹniti o gbagbọ pe Jesu ni Ọmmọ Ọlọrun? Eyi li ẹniti o wá nipa omi on ẹjẹ, ani Jesu Kristi; kì iṣe ni kìki ipa omi, bikoṣe nipa omi on ẹjẹ. Ẹmmí li o sì njẹri, nitoripe otitọ li Ẹmmí na. Nitoripe ẹni mẹta li o njẹri li ọrun, Babba, Ọrọ ati Ẹmmí Mimọ: awọn

Digitized by Google

mẹtẹta yi sì jasi ọkan. Awọn mẹta li o sì njẹri li aiye, Ẹmmí, ati omi, ati ẹjẹ: awọn mẹtẹta yi sì jasi ọkan. Bi awa ba gbà ẹrí enia, ẹrí Ọlọrun pọ̀ju: nitori eyi li ẹrí Ọlọrun ti o ti jẹri nipa ti Ọmmọ rẹ̀. Ẹniti o ba gbà Ọmmọ Ọlọrun gbọ́ o ni ẹrí ninu ara rẹ̀: ẹniti kò ba gbà Ọlọrun gbọ́, o ti mu u li eke; nitoriti kò gbà ẹrí na gbọ́ ti Ọlọrun jẹri nipa ti Ọmmọ rẹ̀. Eyi sì li ẹrí, pe ti Ọlọrun ti fu wa ni ìye ainipẹkun ìye yi si mbẹ ninu ti Ọmmọ rẹ̀. Ẹniti o ba ni Ọmmọ o ni ìye; ẹniti kò ba sì ni Ọmmọ Ọlọrun kò sì ni ìye.

Ihin-rere. Joh. 20. 19.

LI alẹ ijọ kan na, ti iṣe ijọ ekini ọṣẹ, nigbati gbogbo ilẹkun ti sé tan, nibiti awọn ọmmọ ẹhin gbé pejọ si, nitori ìbẹru ti awọn Ju, nigbana ni Jesu wọ̀le, o duro larin wọn, o sì wi fu wọn pe, Alafia fu nyin. Nigbati o sì ti wi bẹ̃ tan, o fi ọwọ́ ati ìha rẹ̀ hàn fu wọn. Nigbana li awọn ọmmọ ẹhin yọ̀, nigbati nwọn ri Oluwa. Jesu sì tún wi fu wọn pe, Alafia fu nyin: bi Babba mi ti rán mi, gẹgẹ bẹ̃li emi sì rán nyin. Nigbati o sì ti wi eyi tan, o mí si wọn, o sì wi fu wọn pe, Ẹ gbà Ẹmmí Mimọ́: ẹṣẹ ẹnikẹni ti ẹnyin ba fi jì, a sì fi jì wọn; ati ẹṣẹ ẹnikẹni ti ẹnyin ba sì da duro, a sì da wọn duro.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKEJI LẸHIN AJINDE.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o fi Ọmmọ rẹ̀ na kanṣoṣo funi, lati jasi ẹbọ ẹṣẹ fu wa, ati si apẹrẹ ìwa-bi-Ọlọrun pẹlu; Fi ore-ọfẹ fu wa, pe nigba-gbogbo ki awa ki o le ma fi ọpẹ́ ọpọlọpọ julọ gbà anfani rẹ̀ allediyele, ati pẹlu

Digitized by Google

lojojumọ ki a ma gbiyanju ati tọ ipasẹ ìwa mimọ julọ rẹ ti o ni ibukún; nitori Jesu Kristi na Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Pet. 2. 19.

EYI ni ore-ọfẹ, nitori ọkkàn sipa Ọlọrun bi enia ba pa ìya mọra, ti o njìya lasan. Nitori ogo kili o wà, nigbati a nlù nyin nitori èṣẹ nyin, bi ẹnyin fi sũru gbà a? ṣugbọn nigbati ẹnyin ba nṣere, bi ẹnyin ba jìya nitori na, ti ẹnyin ba sì fi sũru gbà a, eyiyi ni itẹwọgbà lọdọ Ọlọrun. Nitoripe inu eyi li a pè nyin si: nitori ti Kristi jìya fu wa pẹlu, o làna silẹ fu wa, ki ẹnyin ki o le ma tọ ipasẹ rẹ: ẹniti kò ṣẹ èṣẹkẹṣẹ, ti a kò sì ri arekereke li ẹnu rẹ: ẹni, nigbati nwọn nkẹgan rẹ, ti kò sì pada kẹgan; nigbati o jìya, ẹniti kò sì kìlọ; ṣugbọn o fi ọran rẹ le ẹniti iṣe idajọ ododo lọwọ: ẹniti on tikarare fi ara rẹ rù èṣẹ wa de ori igi, nipe, awa ti ati di okú si èṣẹ, ki a le di ãye si ododo: nipa ìna ẹniti a mu nyin lara da. Nitori ti ẹnyin ti dabi agutan ti o ti nṣìna; ṣugbọn nisisiyi ẹnyin pada si ọdọ Oluṣọ agutan, ati si ọdọ Biṣopu ọkkàn nyin.

Ihin-rere. Joh. 10. 11.

JESU wipe, Emi ni oluṣọ agutan rere: oluṣọ agutan rere fi ẹmmí rẹ fu awọn agutan. Ṣugbọn ẹniti ṣe alagbaṣe, ti kì iṣe oluṣọ agutan, ẹniti awọn agutan kì iṣe ti rẹ, o ri ikokò mbọ, o fi agutan silẹ, o sì sá lọ: ikokò sì mu awọn agutan, o sì fọn wọn ká kiri. Alagbaṣe sá lọ nitoriti ṣe alagbaṣe, kò si náni awọn agutan. Emi ni oluṣọ agutan rere, mo sì mọ awọn agutan mi, mo sì di mimọ fu awọn ti ṣe ti emi. Gẹgẹ bi Babba ti mọ mi, bẽni mo sì mọ Babba: mo si fi ẹmmí mi lelẹ fu awọn agutan. Emi sì li awọn agutan omiran,

Digitized by Google

ti kì iṣe ti agbo yi: awọn li emi kò le ṣe alaìmu wá pẹlu, nwọn yio sì gbohùn mi; agbo kan, ati oluṣọ agutan kan ni yio sì jẹ.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸTA LẸHIN AJINDE.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti nfi imọlẹ otitọ rẹ hàn, awọn ti mbẹ ninu ìṣina, nitori idi eyi pe, ki nwọn ki o le pada bọ́ sinu ipa ọ̀na ododo; Fifu gbogbo awọn ti a gbà sinu ajọ ẹgbẹ Ìsin Kristi, ki nwọn ki o le ma yẹra kuro ninu ohun wọn-ni ti o lodi si ijẹwọ wọn, ki nwọn ki o sì ma tọ gbogbo irú nkan wọn-ni lẹhin ti o ba eyi na ṣe dede; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Pet. 2. 11.

OLUFẸ ọwọn, mo bẹ nyin, bi alejò ati bi èro, ẹ fà sẹhin kuro nipa ifẹkufẹ ara, ti o mba ọkàn jagun; ki ìrin nyin ki o ṣe otitọ ninu awọn Keferi; nipe, bi nwọn ti nsọ̀rọ si nyin bi oluṣe buburu, nipa iṣẹ rere nyin, ti nwọn yio ma wò, ki nwọn ki o le ma yìn Ọlọrun logo li ọjọ ìbẹwo. Ẹ fi ara nyin balẹ fu gbogbo ìlana enia nitoriti Oluwa: bi fu ọba ni, fu ẹniti o bori gbogbo; tabi fu awọn Bãlẹ, fu bi awọn ti ati ọdọ rẹ rán nitori ati ṣẹ awọn oluṣe buburu niṣẹ, ati nitori iyìn awọn ti nṣe rere. Bẽ sá ni ifẹ Ọlọrun, pe ni rere iṣe ki ẹnyin ki o le pa òpe ti awọn enia wère li ẹnu mọ́: bi omnira enia, ati li allo inira fu iboju arankàn, ṣugbọn bikoṣe bi awọn iranṣẹ Ọlọrun. Buyìn fu gbogbo awọn enia. Fẹ ìwa arakọnri, Bẹ̀ru Ọlọrun. Bọ̀wọ fu ọba.

Digitized by Google

Ihin-rere. Joh. 16. 16.

JESU wi fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ pe, niwọn igba diẹ, ẹnyin kì o sì ri mi: ati niwọn igba diẹ ẹ̀wẹ, ẹnyin o sì ri mi, nitoriti emi nlọ sọdọ Babba. Nigbana li omiran ninu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ mba ara wọn ṣe aroye pe, Kili eyi ti o wi fu wa yi, Niwọn igba diẹ, ẹnyin kì o sì ri mi: ati niwọn igba diẹ ẹ̀wẹ, ẹnyin o sì ri mi: ati Nitoriti emi nlọ sọdọ Babba? Nitorina nwọn wipe, Kili eyi ti o wi yi, Niwọn igba diẹ? awa kò mọ̀ ohun ti o wi. Jesu sá ti mọ̀ pe, nwọn nfẹ lati bi on lẽre, o sì wi fu wọn pe, Ẹnyin mbi ara nyin lẽre niti eyi ti mo wipe, Niwọn igba diẹ, ẹnyin kì o sì ri mi: ati niwọn igba diẹ ẹ̀wẹ, ẹnyin o sì ri mi? Lõtọ, lõtọ ni mo wi fu nyin pe, Ẹnyin o ma sọkun, ẹ o sì ma pohùnrere ẹkún, ṣugbọn awọn araiye yio ma yọ̀: inu nyin yio sì baje, ṣugbọn ibinuje nyin li a.o sì sọ di ayọ̀. Nigbati obiri sá wà ninu irobi, a sì ni ibinuje, nitoriti wakati rẹ̀ de: ṣugbọn nigbati o ba sì ti bí ọmmọ na tan, on kò sì ranti irora na mọ́, fu ayọ̀ nitori a bímọ enia si aiye. Nitorina ẹnyin ni ibinuje nisisiyi: ṣugbọn emi o sì tún ri nyin, àiya nyin yio sì yọ̀ kò sì si ẹnikẹni ti yio gbà ayọ̀ nyin lọwọ́ nyin.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸRIN LẸHIN AJINDE.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ nikanṣoṣo ti o le ṣe akoso agidi ifẹ́ ati ifa ọkkàn ti awọn enia ẹlẹṣẹ; Fifu awọn enia rẹ, ki nwọn ki o le ma fẹ ohun ti iwọ fi lelẹ li aṣẹ, ki nwọn ki o sì ma fẹ eyi ti iwọ ṣe ileri si; pe bẽ, ninu

Digitized by Google

onirũru ati ọpọlọpọ ayipada aiye yi, ki àiya wa ki o le fà nitõtọ mọ́, ibiti a gbé le ma ri otitọ ayọ̀; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Jak. 1. 17.

GBOGBO ẹbun rere ati ẹbun ti o pé, oke li o ti wá, o sì sọkalẹ lati ọdọ Babba imọlẹ wá, lọdọ ẹniti kò si onirũru, bẹ̃ni kò si ojiji iyipada. Ninu ifẹ ara rẹ̀ li o fi ọ̀rọ otitọ bí wa, ki awa ki o le ṣe irú akọbi ninu awọn ẹda rẹ̀. Nitorina, arakọuri mi olufẹ, ki olukuluku enia ki o ma yara lati gbọ́, ki o lọra lati fọhùn, ki o lọra lati binu: nitori ti ibinu enia kì iṣiṣẹ ododo Ọlọrun. Nitorina ẹ fi ẽri ati buburu aṣeleke gbogbo lelẹ̀ li apakan, ki ẹnyin ki o sì fi ọkkàn tutù gbà ọ̀rọ alọ́mọ ni, ti o le gbà ọkkàn nyin là.

Ihin-rere. Joh. 16. 5.

JESU wi fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ pe, Nisisiyi emi nlọ sọdọ ẹniti o rán mi; kò sì si ẹnikan ninu nyin ti o bi mi lẽre pe, Nibo ni iwọ nlọ? Ṣugbọn nitoriti mo sọ nkan wọnyi fu nyin, ibinujẹ sì kún ọkkàn nyin. Ṣugbọn li otitọ ni mo wi fu nyin; Anfani ni fu nyin bi mo ba lọ: nitori bi emi kò ba lọ, Olutunu kì o tọ̀ nyin wá; ṣugbọn bi mo ba dide lọ, emi o rán a si nyin. Nigbati o ba sì de, yio fi oyé yé araiye nipa ti ẹṣẹ, ati nipa ti ododo, ati nipa ti idajọ: nipa ti ẹṣẹ, nitoriti nwọn kò gbà mi gbọ́; nipa ti ododo, nitoriti emi nlọ sọdọ Babba mi, ti ẹnyin kò sì ri mi mọ́; nipa ti idajọ, nitoriti a ti ṣe idajọ alade aiye yi. Mo ni nkan pipọ lati sọ fu nyin pẹlu, ṣugbọn ẹnyin kò le gbà wọn nisisiyi. Ṣugbọn nigbati on, ani Ẹmmí otitọ ni ba de, yio sì tọ́

Digitized by Google

nyin si ọna otitọ gbogbo: nitori on kì o sọrọ ti on tikararẹ; ṣugbọn ohunkohun ti o ba gbọ, on ni yio ma sọ: yio sì fi ohun ti mbọ̀ hàn nyin. On yio ma yìn mi logo: nitoriti yio gbà ninu ti emi, yio sì ma fi hàn fu nyin. Ohun gbogbo ti Babba ni ti emi ni: nitorina ni mo ṣe wipe, on yio mu ohun ti emi, yio sì fi hàn fu nyin.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKARUN LẸHIN AJINDE.

Adura.

OLUWA, lati ọdọ ẹniti ohun rere gbogbo ti wá; Fifu awa ọmmọ ọdọ rẹ onirẹlẹ ọkkàn, nipa imísi rẹ mimọ́ ki awa ki o le ma rò nkan wọn-ni ti ṣe rere, ati nipa ifọnahàn rẹ ti o li ãnu, ki awa ki o le ma mu eyi na ṣe; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Jak. 1. 22.

KI ẹnyin ki o ṣe oluṣe ọrọ na, ki ẹ máṣe olugbọ́ nikan, nititàn ara nyin jẹ. Nitori bi ẹnikan ba ṣe olugbọ́ ọrọ na, ti kò ṣe oluṣe, o dabi ọkọnri ti o nwò oju-iyoju rẹ̀ ninu awo-jiji: nitori nigbati o wò ara rẹ̀ tan, o sì ba ti rẹ̀ lọ, lojukan na o sì gbagbé irú enia bi on ti ri. Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba wò inu ofin omnira ni ti o pé, ti o sì duro sinu rẹ̀, ti on kò ṣe olugbọ́ onigbagbé, ṣugbọn bikoṣe oluṣe iṣẹ̀ na, oluwarẹ̀ li a o bukún fu ninu iṣẹ̀ rẹ̀. Bi ẹnikan ninu nyin ba dabi ẹnipe o nsìn Ọlọrun, ti kò sì kò ahọn rẹ̀ ni ijanu, ṣugbọn ti o ntàn ọkkàn ara rẹ̀ jẹ, ìsin Ọlọrun oluwarẹ̀ asan ni. Ìsin mimọ́ ati aìlabawọn niwaju Ọlọrun ati Babba on li eyi, Ati ma bojuwò

Digitized by Google

awọn alaìni-babba ati awọn opó ninu ipọnju wọn, ati ki o sì ma pa ara rẹ mọ́ kuro lọdọ araiye li aìlabawọn.

Ihin-rere. Joh. 16. 23.

LÕTỌ, lõtọ ni mo wi fu nyin, Ohunkohun ti ẹnyin ba bère lọwọ́ Babba li orukọ mi, on yio fifu nyin. Titi di isisiyi ẹnyin kò ti bère ohunkohun li orukọ mi: bère ẹnyin o sì ri gbà, ki ayọ̀ nyin ki o le kún. Nkan wọnyi ni mo ti fi owe sọ fu nyin: ṣugbọn akokò na de, nigbati emi kì yio fi owe sọ fu nyin mọ́, ṣugbọn emi o sọ ti Babba fu nyin gbangba. Li ọjọ na ẹnyin o bère li orukọ mi: emi kò sì wi fu nyin pe, emi yio bère lọwọ́ Babba fu nyin: nitoriti Babba tikararẹ̀ fẹ́ nyin, nitoriti ẹnyin fẹ́ mi, ati ti ẹnyin sì gbagbọ́ pe, lọdọ Ọlọrun ni mo ti jade wá. Emi jade lati ọdọ Babba wá, mo sì wá si aiye: mo fi aiye silẹ ẹ̀wẹ, mo sì lọ sọdọ Babba. Awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ wi fu u pe, Nigbayi ni iwọ nsọ̀rọ gbangba, iwọ kò sì fi owe sọ̀rọ. Nigbayi li o to da wa loju pe, iwọ mọ̀ ohun gbogbo, ati pe iwọ kò ni ki a bi ọ lẽre: nipa eyi li awa gbagbọ́ pe, lọdọ Ọlọrun ni iwọ ti jade wá. Jesu da wọn lohùn pe, Ẹnyin gbagbọ́ nisisiyi bi? Kiyesi i wakati na mbọ̀ wá, ani o de tan nisisiyi, ti a o fọn nyin ká kiri, olukuluku si ilẹ rẹ̀, ẹnyin o sì fi emi nikan silẹ: ṣugbọn kì yio kù emi nikan, nitoriti Babba mbẹ pẹlu mi. Nkan wọnyi ni mo ti sọ fu nyin tẹlẹ, ki ẹnyin ki o le ní alafia lọdọ mi. Lọdọ araiye ẹnyin o ni ipọnju: ṣugbọn ẹ tújuka; mo ti ṣẹgun aiye na.

Digitized by Google

ỌJỌ TI IGÒKE RÈ ỌRUN.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, fifuni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, pe bi awa ti gbà Jesu Kristi gbọ́ Ọmmọ bibi rẹ nikanṣoṣo Oluwa wa, pe o ti gòke lọ si ọrun; bẽni pẹlu li àiya ati ni inu ki awa ki o sì gòke lọ sibẹ, ati pẹlu rẹ titi lai ki a ma gbé, ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu iwọ ati Ẹmmí Mimọ́, Ọlọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Episteli. Iṣe 1. 1.

THEOFILU, ihin ti iṣaju ni mo ti rò, niti gbogbo ohun ti Jesu bẹrẹ si iṣe, ati si ikọ́, titi o fi di ọjọ ti a gbé e lọ soke, lẹhin igba ti o ti fi, fi Ẹmmí Mimọ́ paṣẹ, fu awọn aposteli, ti o ti yàn: ẹniti o sì fi ara rẹ hàn fu lãye lẹhin ìjiya rẹ, ti o li ẹrí pipọ daju-daju, ẹniti a ri lọdọ wọn li ogoji ọjọ, ti o mba wọn sọ̀rọ ohun ti iṣe ti ijọbba Ọlọrun: nigbati o sì ba wọn pejọ, o paṣẹ fu wọn pe, ki nwọn ki o máṣe jade kuro ni Jerusalemu, ṣugbọn ki nwọn ki o duro dè ileri ti Babba, ti o ni, ẹnyin ti gbọ́ li ẹnu mi. Nitõtọ ni Johanu fi omi baptisi; ṣugbọn a o fi Ẹmmí Mimọ́ baptisi nyin kì iṣe ọjọ pipọ lati oni lọ. Nigbati nwọn sì pejọ, nwọn bère lọdọ rẹ pe, Oluwa, lati igba yi lọ, iwọ ki yio fi ijọbba fu Israeli mọ́? O sì wi fu wọn pe, Kì iṣe ti nyin lati mọ̀ igba tabi akokò, ti Babba fi si agbara ọwọ́ ara rẹ. Ṣugbọn ẹnyin o gbà agbara, nigbati Ẹmmí Mimọ́ ba de ọdọ nyin: ẹnyin o sì ma ṣe ẹlẽri mi ni Jerusalemu, ati ni gbogbo Judea, ati ni Samaria, ati titi yio fi de opin ilẹ. Nigbati o sì ti wi nkan wọnyi, bi nwọn

Digitized by Google

ti nwò o, a gbé e soke; awọ sanma sì gbà a kuro li oju wọn. Bi nwọn sì ti tẹ oju mọ́ oju ọrun nigbati o nrè oke, kiyesi i, awọn ọkọnri meji alaṣọ àla duro leti ọdọ wọn; ti nwọn sì wipe, Ẹnyin ọkọnri wọnyi ara Galili, ẽṣe ti ẹnyin fi duro ti ẹnyin ntẹ oju mọ́ oju ọrun? Jesu na yi, ti a gbà soke ọrun kuro lọwọ́ nyin, yio sì tún pada wá gẹgẹ bi ẹnyin ti ri i ti o nlọ si ọrun.

Ihin-rere. Marku 16. 14.

LẸHIN na o sì fi ara hàn fu awọn mọkanla bi nwọn ti joko tì onjẹ, o sì fi àigbagbọ́ ati lile àiya wọn ba wọn wi, nitoriti nwọn kò gbà awọn ti o ti ri i lẹhin igbati o jinde gbọ́. O sì wi fu wọn pe, Ẹ lọ si gbogbo aiye, ki ẹ sì ma wasu Ihin rere fu gbogbo ẹda. Ẹniti o ba gbagbọ́, ti a ba sì baptisi rẹ yio là; ṣugbọn ẹniti kò ba gbagbọ́ yio jẹbi. Àmi wọnyi ni yio sì ma ba awọn ti o gbagbọ́ lọ; Li orukọ mi ni nwọn yio ma lé èṣu jade; nwọn yio sì ma fi ède titun sọ̀rọ; nwọn yio sì ma gbé ejò lọwọ́; bi nwọn ba sì mu ohunkohun ti o li oró, kì yio pa wọn lara; nwọn yio gbé ọwọ́ le awọn olokunrùn, ara wọn yio sì da. Bẹ̃ni nigbati Oluwa sì ti ba wọn sọ̀rọ tan, a sì gbà a lọ soke ọrun, o sì joko li ọwọ́ ọtún Ọlọrun. Nwọn sì jade lọ, nwọn sì nwasu ni ibi gbogbo, Oluwa sì mba wọn ṣiṣẹ, o sì nfi idi ọ̀rọ na kalẹ pẹlu nipa àmi ti ntẹle e.

ỌJỌ ỌLỌRUN LẸHIN IGÒKE RÈ ỌRUN.

Adura.

ỌLỌRUN Ọbba ogo, iwọ ti o gbé Jesu Kristi Ọmmọ rẹ na kanṣoṣo leke si ijọbba

Digitized by Google

rẹ li ọrun ti on ti ogo nla; Awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, máṣe fi wa silẹ laìni itunu; ṣugbọn bikoṣepe ki iwọ ki o rán Ẹmmí Mimọ́ rẹ lati tù wa ninu ki o sì gbé wa leke si ibẹ na ti Kristi Olugbala wa ti lọ ṣaju wa, ẹniti o wà, ti o sì njọba pẹlu iwọ ati Ẹmmí Mimọ́, Ọlọrun kan, aiye aìnipẹkun. *Amin.*

Episteli. 1 Pet. 4. 7.

OPIN ohun gbogbo kùn si dẹdẹ: nitorina ki ẹnyin ki o wà li aìrekọja, ki ẹ sì ma ṣọra si i pẹlu adura. Ati jù gbogbo rẹ lọ, ki ẹ ni ifẹni ti o gbóna ninu ara nyin: nitori ifẹni ni yio bò ọpọlọpọ ẹṣẹ mọlẹ. Ẹ ma ṣe ara nyin li alejò li aìlku sinu. Bi olukuluku ti ri ẹbun na gbà, bẽni ki o ṣe iwá rẹ na fu ọmmọnikeji, bi iriju rere ti ọpọlọpọ ore-ọfẹ Ọlọrun. Bi ẹnikan ba nsọ̀rọ, ki o ma sọ bi ọrọ Ọlọrun; bi ẹnikẹni ba nṣe iṣẹ alufa, ki o ṣe e bi agbara ti Ọlọrun fifu u: ki a le ma yìn Ọlọrun logo li ohun gbogbo nipa Jesu Kristi, ẹniti iyìn ati ijọba wà fu lai ati lailai. Amin.

Ihin-rere. Joh. 15. 26, ati apakan ti Kap. 16.

NIGBATI Olutunu na ba de, ẹniti emi o rán si nyin lati ọdọ Babba wá, ani Ẹmmí otitọ ni, ẹniti nti ọdọ Babba wá, on yio sì jẽri mi: ati ẹnyin pẹlu yio sì jẽri mi, nitoriti ẹnyin ti wà pẹlu mi lati ipilẹṣẹ wá. Nkan wọnyi ni mo ti sọ fu nyin, ki a má ba mu nyin ṣẹ̀. Nwọn o lé nyin kuro ninu sinagogu: ani, akokò na mbọ̀, nigbati ẹnikẹni ti o ba pa nyin, yio rò pe on nṣe ìsin fu Ọlọrun. Ati gbogbo nkan wọnyi ni nwọn yio se si nyin, nitoriti nwọn kò mọ̀ Babba, nwọn kò sì mọ̀

Digitized by Google

mi. Ṣugbọn nkan wọnyi ni mo ti wi fu nyin pe, nigbati akokò na ba de, ki ẹnyin ki o le ranti pe, mo ti sọ fu nyin nitori wọn.

ỌJỌ ỌLỌRUN FUNFUN TI A NPÈ NI.

PENTEKOSTI.

Adura.

OLỌRUN, iwọ bi igba akokò yi ti o kó àiya awọn enia rẹ olõtọ, nipa ríran imọlẹ ti Ẹmmí Mimọ́ rẹ si wọn; Fifu wa nipa Ẹmmí na ki a le ni ìro rere ninu ohun gbogbo, ati siwaju ki a ma yò ninu itunu rẹ mimọ́; nipasẹ itoye Jesu Kristi Olugbala wa, ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu iwọ, ninu iṣọkan ti Ẹmmí na, Ọlọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Epistéli. Iṣe 2. 1.

NIGBATI ọjọ Pentekosti sì pé tan, gbogbo nwọn fi ọkkàn kan wà nibi kan. Lojijì iró sì ti ọrun wá, gẹgẹ bi iró efufu lile, o sì kún gbogbo ile nibiti nwọn gbé joko. Èla ahọn bi ti iná sì yọ si wọn, o sì bà le olukuluku wọn. Gbogbo wọn sì kún fu Ẹmmí Mimọ́, nwọn sì bẹrẹ si ifi ède omiran fọ, gẹgẹ bi Ẹmmí ti fu wọn li ohùn. Awọn Ju enia rere sì wà ti nṣe atipo ni Jerusalemu, lati orilẹ ède gbogbo wá ti mbẹ labbẹ ọrun. Nigbati a sì ti ròhin eyi yiká, ọpọlọpọ enia pejọ, nwọn sì damu, nitoriti olukuluku gbọ́ nwọn nsòrọ li ède rẹ. Hà sì ṣe gbogbo wọn, ẹnu sì yà wọn, nwọn nwi fu ara wọn pe, Kiyesi i, gbogbo awọn wọnyi ti nsòrọ kì iṣe ara Galili? Eha sì ti ṣe ti olukuluku enia fi ngbọ́ li ède wa, nibiti a gbé bí wa? Ara Partia, ati ara

Digitized by Google

Media, ati ara Elamu, ati awọn ti ngbé Mesopotamia, ati ni Judea, ati Kapadokia, ni Pontu, ati Asia, Frigia, ati Pamfilia, ni Egipti, ati li apa ìha Libia niha Kirene, ati awọn atipo ara Romu, awọn Ju ati awọn alawọṣe Ju, ara Krete ati awọn ara Arabia, awa gbọ́ nwọn nsọ̀rọ isẹ̀ iyanu nla Ọlọrun li ède wa.

Ihin-rere. Joh. 14. 15.

JESU sọ fu awọn ọmmọ ehin rẹ̀ pe, Bi ẹnyin ba fẹ mi, ẹ pa ofin mi mọ́. Emi o sì bère lọwọ́ Babba, on yio sì fu nyin li Olutunu omiran, ki o le ma ba nyin gbé titi lailai; ani Ẹmmí Otitọ ni; ẹniti araiye kò le gbà, nitoriti kò ri i, bẽni kò sì mọ̀ ọ: ṣugbọn ẹnyin mọ̀ ọ; nitoriti o ngbé inu nyin, on yio sì ma wà ninu nyin. Emi kì o fi nyin silẹ̀ li alaìni Babba: emi yio tọ̀ nyin wá. Niwọn igba diẹ̀, aiye kì o sì ri mi mọ́; ṣugbọn ẹnyin ri mi: nitoriti mo wà lãye, ẹnyin o sì wà lãye pẹlu. Li ọjọ́ na li ẹnyin o mọ̀ pe, emi wà ninu Babba mi, ati ẹnyin ninu mi, ati emi ninu nyin. Ẹniti o ba li ofin mi, ti o ba sì npa wọn mọ́, on na li ẹniti o fẹ mi: ẹniti o ba sì fẹ mi, a o fẹ ẹ lati ọdọ Babba mi wá, emi yio sì fẹ ẹ, emi o sì fi ara mi hàn fu u. Juda sì wi fu u, (ki má ṣe Iskariotu) pe, Oluwa, iwọ yio ti fi ara rẹ̀ hàn fu wa, ti kì yio sì ṣe fu araiye? Jesu dahùn o sì wi fu u pe, Bi ẹnikan ba fẹ mi, on yio sì pa ọ̀rọ̀ mi mọ́: Babba mi yio sì fẹ ẹ, awa o sì ma tọ̀ ọ wá, awa o sì ṣe ibugbe wa pẹlu rẹ̀. Ẹniti kò fẹ mi ni kò pa ọ̀rọ̀ mi mọ́: ati ọ̀rọ̀ na ti ẹnyin gbọ́ kì iṣe ti emi, ṣugbọn ti Babba ti o rán mi. Nkan wọnyi li emi nsọ fu nyin, niwọn igba ti mo wà pẹlu nyin. Ṣugbọn

Digitized by Google

Olutunu na, ti ṣe Ẹmmí Mimọ́, ẹniti Babba yio rán li orukọ mi, on ni yio kọ́ nyin li ohun gbogbo, yio sì mu ohun gbogbo wá si iranti nyin, ohunkohun ti mo ti sọ fu nyin. Alafia ni mo fi silẹ fu nyin, alafia mi ni mo fifu nyin: kì iṣe gẹgẹ bi aiye ti fi funi, ni mo fifu nyin. Ẹ máṣe jẹ ki ọkkàn nyin bajẹ, ki ẹ má sì jẹ ki o wa-rìri. Ẹnyin sá ti gbọ́ bi mo ti wi fu nyin pe, Emi nlọ, emi o sì tún pada tọ̀ nyin wá. Ẹnyin iba fẹ mi, ẹnyin iba ma yọ̀ nitoriti mo wipe, Emi nlọ sọdọ Babba: nitoriti Babba mi tobijù mi lọ. Emi sì ti wi fu nyin tẹlẹ nisisiyi ki o to de, nigbati o ba de, ki ẹnyin ki o le gbagbọ́. Lẹhin eyi emi kì o sọ ọ̀rọ̀ pipọ fu nyin: nitori alade aiye yi wá, kò sì ni nkan kan lọdọ mi. Ṣugbọn nitori ki araiye ki o le mọ̀ pe emi fẹ Babba; gẹgẹ bi Babba sì ti fi aṣẹ fu mi, bẽni mo sì ṣe.

Monday ni ọsẹ funfun.

Epistoli. Isẹ 10. 34.

NIGBANA ni Peteru yà ẹnu rẹ̀, o ni, Nitõtọ mo woye pe, Ọlọrun kì iṣe ojusaju enia: ṣugbọn ninu gbogbo orilẹ èdè, ẹniti o ba bẹ̀ru rẹ̀, ti o si ṣe otitọ, gbigbà ni lọdọ rẹ̀. Ọ̀rọ̀ ti Ọlọrun rán si awọn ọmmọ Israeli, ti nwasu alafia nipa Jesu Kristi: (on li Oluwa ohun gbogbo:) Ọ̀rọ̀ na ẹnyin mọ̀, ti a ti wasu yiká gbogbo Judea, ti a bẹ̀rẹ si lati Galili wá, lẹhin baptismu ti Johanu wasu; bi Ọlọrun ti dà Ẹmmí Mimọ́ ati ọlá si Jesu ti Nasareti lori: ẹniti o nkiri lati ṣe ore, ati lati ṣe diẽa ara gbogbo awọn ti ara kan fu èṣu; nitoriti Ọlọrun wà pẹlu rẹ̀. Awa sì li ẹlẽri gbogbo ohun ti o ṣe, ati ni ilẹ ti awọn Ju, ati ni

Digitized by Google

Jerusalemu; ẹniti nwọn pa, ti nwọn sì fi há lori igi: on li Ọlọrun jinde ni ijọ ẹkẹta, o sì fi i hàn nigbangba; kò ṣepe fu gbogbo enia, bikoṣe fu awọn ẹlẽri ti a ti yàn tẹlẹ lati ọdọ Ọlọrun wá, fu awa, ti awa ba a jẹ, ti awa sì ba a mu lẹhin igbati o jinde kuro ninu okú. O sì rán wa lọ lati wasu fu awọn enia na, ati lati jẽri pe, on li a yàn lati ọdọ Ọlọrun ṣe Onidajọ ãye on okú. On ni gbogbo awọn woli jẽri fu pe, ẹnikẹni ti o ba gbagbọ́ li orukọ rẹ̀, yio ri imukuro ẹ̀ṣẹ̀ gbà. Bi Peteru sì ti nsọ̀rọ̀ wọnyi li ẹnu, Ẹmmí Mimọ́ bà le gbogbo awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ̀ na. Hà sì ṣe awọn onilà ti o gbagbọ́, ìwọn awọn ti o ba Peteru wá, nitoriti ẹ̀bun ti Ẹmmí Mimọ́ dà lu awọn Keferi pẹlu. Nitori nwọn gbọ́, nwọn nfi ède omiran fọ̀, nwọn sì nyìn Ọlọrun logo. Nigbana ni Peteru dahùn wipe, Ẹnikẹni le sofin omi, ki a má fi baptisi awọn wọnyi, ti nwọn gbà Ẹmmí Mimọ́ gẹ̀gẹ̀ bi awa? O sì ni ki a baptisi wọn li orukọ Oluwa. Nigbana ni nwọn bẹ̀ ẹ ki o duro ni ijọ melokan.

Ihin-rere. Joh. 3. 16.

OLORUN fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmmọ bíbi rẹ̀ nikanṣoṣo funi, pe ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ kì yio ṣegbé, ṣugbọn yio ni ìyè ti kò nipẹkun. Nitori Ọlọrun kò rán Ọmmọ rẹ̀ si aiye lati da araiye lẹbi; ṣugbọn ki a le ti ipasẹ rẹ̀ gbà araiye là. Ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́, a kì yio da a lẹbi; ṣugbọn a ti da ẹniti kò gbà a gbọ́ lẹbi na, nitoriti kò gbà orukọ Ọmmọ bíbi kanṣoṣo ti Ọlọrun gbọ́. Eyi sì li ẹbi pe, imọlẹ wá si aiye, awọn araiye sì fẹ òkunkun jù imọlẹ lọ, nitoriti iṣẹ̀ wọn buru. Nitori ẹnikẹni ti o ba ṣe buburu ni

Digitized by Google

ikorira imọlẹ, bẹ̃ni kò sì jẹ wá si ibi imọlẹ, ki a máṣe ba iṣẹ rẹ̀ wi. Ṣugbọn ẹniti o ba ṣe otitọ ni iwá si imọlẹ, ki iṣẹ rẹ̀ ki ọ le fi ara hàn pe, a ṣe wọn nipa ti Ọlọrun.

TUESDAY NI ỌSẸ FUNFUN.

Episteli. Iṣe 8. 14.

NIGBATI awọn aposteli ti o wà ni Jerusalemu gbọ́ pe awọn ara Samaria gbà ọrọ Ọlọrun, nwọn rán Peteru on Johanu si wọn: awọn ẹniti o sì gbadura fu wọn, nigbati nwọn sọkalẹ, ki nwọn ki o le ri Ẹmmí Mimọ́ gbà: (nitori titi o fi di igba na kò ti ibà le ẹnikẹni ninu wọn: ṣugbọn kìki a baptisi wọn li orukọ Jesu Oluwa ni.) Nigbana ni nwọn fi ọwọ́ le wọn, nwọn sì gbà Ẹmmí Mimọ́.

Ihin-rere. Joh. 10. 1.

LÕTỌ, lõtọ ni mo wi fu nyin, Ẹnikẹni ti kò ba gbà ẹnu ọ̀na wọ̀ inu agbo agutan, ṣugbọn ti o ba gbà ibi omiran gùn oke, on na li olè ati kólekole. Ṣugbọn ẹniti o ba ti ẹnu ọ̀na wọ̀le, on ni iṣe oluṣọ agutan. On ni oludèna ṣilẹkun fu; awọn agutan sì gbohùn rẹ̀: o sì pè awọn agutan ti rẹ̀ li orukọ, o sì ṣe amọ̀na wọn jade. Nigbati o sì mu agutan ti rẹ̀ jade, o ṣiwaju wọn, awọn agutan na sì ntọ̀ ọ lẹhin: nitoriti nwọn mọ̀ ohùn rẹ̀. Nwọn kì itọ̀ alejò lẹhin, ṣugbọn nwọn a ma sá lọdọ rẹ̀: nitoriti nwọn kò mọ̀ ohùn alejò. Owe yi ni Jesu pa fu wọn: ṣugbọn oyé nkan wọn-ni ti o fi nsọ̀rọ fu wọn kò yé wọn. Nigbana ni Jesu tún wi fu wọn pe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi

Digitized by Google

fu nyin, Emi ni ilẹkun ti awọn agutan. Olè ati ọlọṣà ni gbogbo awọn ti o ti wá ṣiwaju mi: ṣugbọn awọn agutan kò gbọ́ ohùn wọn. Emi ni ilẹkun: lati ọdọ mi bi ẹnikan ba wọle, on li a o gbà là, on yio wọle yio sì jade, yio sì ri koriko. Olè kò wá, bikoṣepe lati jale, ati lati pa, ati lati parun: emi wá ki nwọn ki o le ni ìye, ani ki nwọn ki o le ni i gidigidi lọpọlọpọ.

ỌJỌ ỌLỌRUN TI MẸTALỌKAN.

Adura.

OLỌRUN ati aiye-raiye Olodumare, iwọ ti o ti fu awa iranṣẹ rẹ li ore-ọfẹ, nipa ijẹwọ otitọ igbagbọ́, lati jẹwọ ogo ti Mẹtalọkan aiye-raiye, ati ni agbara ti Ọlá-nla Ọlọrun lati sìn Iṣọkan na; Awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o le pa wa mọ́ ni iduro ṣinṣin ninu igbagbọ́ yi, ati titi lai ki o dãbobo wa ninu ipọnju gbogbo, ẹniti o wà ti o sì njọba, lai Ọlọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Epistéli. Ifihàn 4. 1.

LẸHIN eyi li emi wò, sì kiyesi i, ilẹkun kan ṣí silẹ li ọrun: ohùn ti mo sì tètekọ gbọ́ dabi ti ìpe ti mba mi sọ̀rọ; ti o wipe, Wá loke nihin, emi o sì fi ohun ti yio hù nigba ikẹhin hàn fu ọ. Lojukan na mo sì wà ninu Ẹmmí: sì kiyesi i, a tẹ́ itẹ́ kan li ọrun, ẹnikan sì joko lori itẹ́ na. Ẹniti o sì joko jẹ́ ẹniti a ba ma wò bi okuta jaspi, ati sardi: oṣumare sì ta yi itẹ́ na ká kiri, ni wiwò rẹ̀ bi okuta smaragdu. Ati ọgba yi itẹ́ na ká ni ibujoko mẹrinlelogun: ati lori

Digitized by Google

ibujoko na mo ri awọn alàgba mẹrinlelogun joko, ti a wọ̀ li aṣọ àla; nwọn sì ni ade wura li ori wọn. Ati lati ibi itẹ̀ na ni manamana ati ãrá ati ohùn ti jade wá: fitila iná meje sì ntàn nibẹ̀ niwaju itẹ̀ na, ti iṣe Ẹmmí meje ti Ọlọrun ni. Ati niwaju itẹ̀ na, okun digí kan wà o dabi kristali: ati li arin itẹ̀ na, ati rọgba yi itẹ̀ na ká, li ẹda mẹrin ti o kún fu oju ati niwaju ati lẹhin. Ẹda ekini sì dabi kiniu, ẹda ekeji sì dabi ọmmọ malu, ẹda ẹkẹta sì ni oju bi ti enia, ẹda ẹkẹrin sì dabi idì ti nfò. Ati olukuluku awọn ẹda mẹrẹrin sì ni apaiyẹ̀ mẹfa-mẹfa yi i ká; nwọn sì kún fu oju ninu: nwọn kò sì simi li ọsán ati li oru, wipe, Mimọ́, mimọ́, mimọ́, Oluwa Ọlọrun Olodumare, ti o ti wà, ti o sì mbẹ, ti o si mbọ̀wa. Nigbati awọn ẹda wọn-ni sì fi ogo ati ọlá, ati ọpẹ́ fu ẹniti o joko lori itẹ̀ ni, ti o mbẹ lãye lai ati lailai, awọn alàgba mẹrinlelogun na wolẹ niwaju ẹniti o joko lori itẹ̀, nwọn sì tẹriba fu ẹniti mbẹ lãye lai ati lailai ni, nwọn sì fi ade wọn lelẹ niwaju itẹ̀ na, wipe, Oluwa, iwọ li o yẹ lati gbà ogo ati ọlá ati agbara: nitoripe iwọ li o da ohun gbogbo, ati nitori wiwù rẹ ni nwọn fi wà ti a sì ṣe da wọn.

Ihin-rere. Joh. 3. 1.

OKỌNRI kan wà ninu awọn Farisi, ti a npè ni Nikodemu, ijoye kan ninu awọn Ju: on na li o tọ̀ Jesu wá li oru, o sì wi fu u pe, Rabi, awa mọ̀ pe olukọni otitọ lati ọdọ Ọlọrun wá ni iwọ ṣe: nitoripe kò si ẹniti o le ṣe iṣẹ iyanu wọnyi ti iwọ nṣe, bikoṣepe Ọlọrun wà pẹlu rẹ̀. Jesu dahùn o sì wi fu u pe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi fu ọ, Bikoṣepe a tún enia bí, on kì yio le ri ijọba Ọlọrun. Nikodemu wi fu u pe, A o ti ṣe le tún enia bí,

Digitized by Google

nigbati o di agbalagba tan? o sì le tún wọ́ inu iya rẹ̀ lọ nigba ekeji, ki a sì tún ọ bí? Jesu dahùn wipe, Lõtọ́, lõtọ́ ni mo wi fu ọ, Bikoṣepe a tun enia bí nipa ti omi, ati nipa ti Ẹmmí, on kì yio le wọ́ ijọba Ọlọrun. Eyiti a bí nipa ti ara, ara ni; eyiti a sì bí nipa ti Ẹmmí, ẹmmí ni. Ki ẹnu ki o máṣe yà ọ, nitori eyiti mo wi fu ọ pe, A kò le ṣe alaìtún nyin bí. Afẹfẹ nfẹ si ibi ti o gbé wù u, iwọ sì ngbọ́ iró rẹ̀, ṣugbọn iwọ kò mọ́ ibi ti o gbé ti wá, ati ibi ti o gbé nlọ: gẹgẹ bẽli gbogbo awọn ẹniti a bí nipa ti Ẹmmí. Nikodemu dahùn, o sì wi fu u pe, Nkan nwọnyi yio ti ṣe le ri bẹ̀? Jesu dahùn, o sì wi fu u pe, Iwọ ti ṣe olukọni ni Israeli, kò sì mọ́ nkan nwọnyi? Lõtọ́, lõtọ́ ni mo wi fu ọ, Awa nsọ eyiti awa mọ́, awa sì njẽri eyiti awa ri; ẹnyin kò sì gbà ijẽri wa. Bi mo ba ti sọ̀rọ ohun ti aiye yi fu nyin, ti ẹnyin kò gbagbọ́, ẹnyin o ti ṣe gba-gbọ́ bi mo ba sọ ohun ti ọrun fu nyin? Kò sì si ẹnikẹni fi o gòke rè ọrun, bikoṣe ẹniti o ti ọrun sọkalẹ wá, eyini li Ọmmọ ọkọnri na ti mbẹ li ọrun. Bi Mose sì ti gbé ejò soke li aginjù, gẹgẹ bẽli a kò le ṣe alaìgbé Ọmmọ ọkọnri soke pẹlu: pe ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́, ki o má ba ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ti kò nipẹkun.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKINI LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLỌRUN, agbara ti gbogbo awọn ti o gbẹ̀kẹ̀ wọn le ọ, fi ãnu gbà adura wa; ati nitori allera ìwa ẹda kikú wa, awa kò le ṣe ohun rere kan lẹhin rẹ, fu wa ni iranlọwọ́ ti ore-ọfẹ rẹ, pe ni ipamọ́ ọfin rẹ ki awa ki o le wù

Digitized by Google

ọ, ati ni ifẹ ati ni iṣe; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Joh. 4. 7.

OLUFE, ẹ jẹ ki a fẹ ara wa: nitoripe ifẹ ni ti Ọlọrun; ati gbogbo ẹniti o ba fẹ ni a bí i nipa ti Ọlọrun, o sì mọ Ọlọrun. Ẹniti kò ba ṣe ifẹ kò mọ Ọlọrun; nitoripe Ọlọrun ni ifẹ. Ninu eyi li a gbé fi ifẹ Ọlọrun hàn si wa, nitoriti Ọlọrun rán Ọmmọ bíbi rẹ̀ nikanṣoṣo si aiye yi, ki awa ki o le yè nipasẹ rẹ̀. Nipa eyi ni ifẹ, kì iṣe pe ti awa fẹ Ọlọrun, bikoṣe pe ni ti o fẹ wa, ti o sì rán Ọmmọ rẹ̀ ṣe ètutu fu ẹ̀ṣẹ wa. Olufẹ, bi Ọlọrun ba fẹ wa tobẹ̃, o sì yẹ ki awa ki o fẹ ara wa pẹlu. Ẹnikẹni kò ri Ọlọrun nigba kan ri. Bi awa ba fẹ ara wa, Ọlọrun mba wa gbé inu wa, a sì mu ifẹ rẹ̀ pé ninu wa. Nipa eyi li awa mọ pe awa mba a gbé inu rẹ̀, ati on ninu wa, nitoriti o ti fi Ẹmmí rẹ̀ fu wa. Awa sì ti ri, a sì jẹri, pe Babba rán Ọmmọ lati ṣe Olugbala fu araiye. Ẹnikẹni ti o ba jẹwọ pe Jesu Ọmmọ Ọlọrun ni, Ọlọrun mba a gbé inu rẹ̀, ati on ninu Ọlọrun. Awa sì ti mọ, a sì gbà ifẹ ti Ọlọrun ni si wa gbọ́. Ọlọrun ni ifẹ; ẹniti o ba sì ngbé inu ifẹ o ngbé inu Ọlọrun, ati Ọlọrun ninu rẹ̀. Nipa eyi li a mu ifẹ wa pé, ki awa ki o le ni igboiya li ọjọ idajọ: nitoripe bi o ti ri, bẹ̃li awa sì ri li aiye yi. Ìbẹru kò si ninu ifẹ; ṣugbọn ifẹ ti o pé o lé ìbẹru jade: nitoriti ìbẹru ni oró. Ẹniti o bẹ̀ru kò pé ninu ifẹ. Awa fẹ ẹ, nitoriti on tète fẹ wa. Bi ẹnikan ba wipe, Emi fẹ Ọlọrun, ti o sì korira arakọnri rẹ̀, eleke ni: nitori ẹniti kò fẹ arakọnri rẹ̀ ti o ri, yio ti ṣe fẹ Ọlọrun ti on kò ri? Ofin yi li awa sì ri

Digitized by Google

gbà lati ọwọ́ rẹ̀ wá, Pe ẹniti o ba fẹ Olọrun, o fẹ arakọnri rẹ̀ pẹlu.

Ihin-rere. Luku 16. 19.

OKỌNRI kan ọlọrọ̀ ti wà, ti o nwọ̀ aṣọ elesè àluko ati aṣọ àla daradara, a sì ma jẹ didùndidùn lojojumọ́: alagbe kan sì wà ti a npè ni Lasaru, ti nwọn ima gbé wá kalẹ lẹba ọna ile rẹ̀, ara rẹ̀ kún fu õju, on a sì ma fẹ ki a fi ẹrún ti o ti ori tabeli ti ọlọrọ̀ bọ silẹ bọ́ on: bẽli awọn ajá sì de, nwọn sì fa a li õju lá. O sì ṣe, nigbati alagbe kú, a sì ti ọwọ́ awọn angeli gbé e lọ si àiya Abrahamu: ọlọrọ̀ na sì kú pẹlu, a sì sin i; li ọrun apadi li o ti gbé oju rẹ̀ soke, o mbẹ ninu iṣẹ oró, o sì ri Abrahamu li òkere, ati Lasaru li àiya rẹ̀. O sì ke, o wipe, Babba Abrahamu, ṣãnu fu mi, ki o sì rán Lasaru, ki o fi orika rẹ̀ bọmi, ki o sì fi tù mi li ahọn; nitoriti emi nṣiṣẹ oró ninu ọwọ́ iná yi. Ṣugbọn Abrahamu wi fu u pe, Ọmmọkọnri, ranti pe, nigbati iwọ mbẹ li aiye iwọ ti gbà ohun rere ti rẹ tan, ati Lasaru ohun buburu: ṣugbọn nisisiyi ara rọ̀ ọ, iwọ sì nṣiṣẹ oró. Ati pẹlu gbogbo eyi, ọgbọn nla li a fi da awa ati ẹnyin lagbedemeji: bẽli awọn ti nfẹ, kò le rekọja si nyin lati ihin lọ; bẽli awọn ti sì nfẹ, kò le rekọja si wa lati ibẹ̀ wá. O sì wipe, Njẹ mo bẹ̀ ọ, babba, ki iwọ ki o le rán a lọ si ile babba mi: nitoriti mo ni arakọnri marun; ki o le rò fu wọn, ki nwọn ki o má ba wá si ibi iṣẹ oró yi pẹlu. Abrahamu sì wi fu u pe, Nwọn ni Mose ati awọn woli; ki nwọn ki o gbọ́ wọn. O sì wi fu u pe, Bẽkọ, babba Abrahamu: ṣugbọn bi ẹnikan ba ti inu okú tọ̀ wọn lọ, nwọn o ronupiwada. O sì wi fu u pe, Bi nwọn kò ba gbọ́ Mose ati awọn woli,

Digitized by Google

nwọn kì yio yi ọkkàn pada bi ẹnikan tilẹ ti inu okú dide.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKEJI LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, iwọ ti kò tì lati ṣe iranlọwọ ati akoso awọn ti iwọ tọ́ ninu ìbẹru ati ifẹ́ rẹ, ti o duro ṣinṣin; Pa wa mọ́, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, labbẹ àbo ìpese rere rẹ, ki o sì mu wa ki a ma ni ìbẹru ati ifẹ́ ti Orukọ mimọ́ rẹ titi lọ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Joh. 3. 13.

KI ẹnu ki o máṣe yà nyin, ẹnyin arakọnri mi, bi aiye ba korira nyin. Awa mọ pe awa ti kọja lati inu ikú sinu ìye, nitori ti awa fẹ awọn arakọnri. Ẹnikẹni ti kò ba fẹ arakọnri rẹ o ngbé inu ikú. Ẹnikẹni ti o ba korira arakọnri rẹ on ni olupani: ẹnyin sì mọ pe ìye aìnipẹkun kò le ba olupani kan gbé. Nipa eyi li awa mọ ifẹ́ Ọlọrun, nitoriti o fi ẹmmí rẹ lelẹ fu wa: o sì yẹ ki awa fi ẹmmí wa lelẹ fu awọn arakọnri. Ṣugbọn ẹniti o ba ni ohun rere ti aiye yi, ti o sì ri arakọnri rẹ ti iṣe alaìni, ti o sì sé iyọnu rẹ si i, ifẹ́ Ọlọrun yio ha ti bá oluwarẹ gbé? Ẹnyin ọmmọde mi, ẹ máṣe jẹ ki a fi kìki ẹnu ṣe ifẹ́, tabi kìki ahọn; bikoṣe ni iṣe ati ni otitọ. Ati nipa eyi li awa mọ pe awa mbẹ ni ti inu otitọ, ati pe awa o sì ṣe dajudaju ọkkàn wa niwaju rẹ. Nitori bi ọkkàn wa ba da wa lẹbi, Ọlọrun tobi jù ọkkàn wa lọ, o sì mọ ohun gbogbo. Olufẹ bi ọkkàn wa kò ba da wa lẹbi, njẹ awa ni igbẹkẹle sipa ti Ọlọrun. Ati ohunkohun ti awa ba bère, awa ri gbà lọdọ

Digitized by Google

rẹ̀, nitori ti awa pa ofin rẹ̀ mọ́, ti awa sì nṣe nkan wọn-ni ti o ṣe ohun ìwu niwaju rẹ̀. Eyi sì li ofin rẹ̀, Pe ki awa ki o le gbà orukọ Jesu Kristi Ọmmọ rẹ̀ gbọ́, ki a sì fẹ ara wa, gẹ̀gẹ̀ bi o ti fi ofin fu wa. Ẹniti o ba sì pa ofin rẹ̀ mọ́ o mba a gbé inu rẹ̀, ati on ninu rẹ̀. Ati nipa eyi li awa mọ̀ pe o mba wa gbé inu wa, nipa Ẹmmí ti o fifu wa.

Ihin-rere. Luku 14. 16.

OKỌNRI kan se àse alẹ nla, o sì pè awọn enia pipọ: O sì rán onisẹ̀ rẹ̀ ni wakati àse alẹ, ki o wi fu awọn ti a ti pè tẹlẹ pe, Ẹ wá; nitori ohun gbogbo ṣe tan. Gbogbo wọn sì bẹ̀rẹ̀ li ohùn kan lati ma wawi. Ekini wi fu u pe, Emi rà ilẹ kan biri bayi, emi kò le ṣe ki nmá lọ lati wò o: mo bẹ̀ ọ ki a ṣe gafara fu mi. Ekeji sì wipe, Emi rà ajaga malu marun, emi sì nlọ lati dan wọn wò: mo bẹ̀ ọ ki a ṣe gafara fu mi. Ẹkẹta sì wipe, Emi gbeyawo, nitorina li emi kò fi le wá. Nigbati onisẹ̀ pada de, o sì sọ gbogbo nkan wọnyi fu oluwa rẹ̀. Nigbana ni bãle ile binu, o wi fu onisẹ̀ rẹ̀ pe, Jade lọ nisisiyi si igboro ilu, ati si abuja ọ̀na igboro ilu, ki iwọ ki o sì mu awọn talakà, ati awọn alabukun arun, ati awọn amõkun, ati awọn afọju wá si ihinyi. Onisẹ̀ na sì wipe, Oluwa, a ṣe bi o ti wi tan, àye sì mbẹ̀ ni ile. Oluwa sì wi fu onisẹ̀ na pe, Jade lọ si opópo, ati si ipa ọ̀na ọgbà, ki iwọ ki o sì rọ̀ wọn ki nwọn ki o wá, ki a le mu ile mi kún. Ki emi ki o wi fu nyin, Ẹnikẹni ninu awọn ti a ti pè, kì yio tọwò ninu àse alẹ mi.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸTA LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi ãnu gbọ́ ti wa; ki o sì fifuni, pe awa, ẹniti iwọ fi ifẹ́ atàiyawa fu lati ma gbadura, nipa iranlọwọ agbara rẹ, ki a le ma dãbobo wa, ati ki a le ma tù wa ninu, ninu gbogbo ewu ati ipọnju wa; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Pet. 5. 5.

GBOGBO nyin ẹ ma foribalẹ fu ara nyin, ki a sì fi irẹlẹ wọ́ nyin li aṣọ: nitori ti Ọlọrun kọjùjasi awọn onirera, ṣugbọn o fi ore-ọfẹ fu awọn onirẹlẹ ọkkàn. Nitorina ẹ rẹ̀ ara nyin silẹ labbẹ ọwọ́ agbara Ọlọrun, ki on ki o sì gbé nyin leke li akokò: ẹ ma kó gbogbo aniyan nyin le e lọwọ́; nitori ti o nṣe aniyan nyin. Ẹ ma wà li alrekọja, ẹ ma ṣọra; nitori èṣu ọtá nyin, bi kiniu ti nke ramuramù, o nrìn ká kiri, o nwá ẹniti yio paję kiri: ẹniti ki ẹnyin ki o kọjùjasi girigiri nipa igbagbọ́, ki ẹnyin ki o mọ́ pe ipọnju na ti ṣẹ ninu awọn arakọnri nyin ti o wà li aiye. Ṣugbọn Ọlọrun ti ore-ọfẹ gbogbo, ti o pè wa sinu ogo rẹ̀ ti kò nipẹkun nipa Kristi Jesu, nigbati ẹnyin ba jìya nigba diẹ, ki o ṣe nyin li aṣepé, ki o fi ẹsẹ nyin mulẹ, ki o fu nyin li agbara, ki o fi idi nyin kalẹ. On li ogo ati agbara mbẹ fu lái ati lailai. Amin.

Ihin-rere. Luku 15. 1.

NIGBANA ni gbogbo awọn agbowode ati ẹlẹṣẹ sumọ́ ọ lati gbọ́ ọrọ rẹ̀. Ati awọn Farisi ati awọn akọwe nkù, wipe, Ọkọnri yi ngbà ẹlẹṣẹ, o sì mba wọn jẹun. O sì pa owe

Digitized by Google

yi fu wọn, wipe, Ọkọnri ewo ni ninu nyin, ti o ni ọgọrun agutan, bi o ba sọ ọkan nù ninu wọn, ti kì yio fi mọkandilọgọrun iyokun silẹ ni pápa, ti kì yio si tọsẹ eyi ti o nù lọ, titi yio fi ri i? Nigbati o si ri i tan, o gbé e le ejika rẹ̀, o nyọ̀. Nigbati o si de ile, o pè awọn ọrẹ́ ati aladugbo rẹ̀ jọ, o nwi fu wọn pe, Ẹ ba mi yọ̀; nitoriti mo ri agutan mi ti o ti nù. Ki emi ki o wi fu nyin, gẹgẹ bẹ̃li ayọ̀ yio wà li ọrun lori ẹlẹṣẹ kan ti o ronupiwada, jù lori olõtọ mọkandilọgọrun lọ, ti o ṣe alaìni ironupiwada. Tabi obiri ewo li o ni fadaka mẹwa, bi o ba sọ ọkan nù, ti kì yio tàn fitilà, ti kì yio gbá ile, ti kì yio wá a gidigidi titi yio fi ri i? Nigbati o si ri i, o pè awọn ọrẹ́ ati awọn aladugbo rẹ̀ jọ, o wipe, Ẹ ba mi yọ̀; nitoriti mo ri fadakà ti mo ti sọnù. Ki emi ki o wi fu nyin, gẹgẹ bẹ̃li ayọ̀ mbẹ niwaju awọn angeli Ọlọrun lori ẹlẹṣẹ kan ti o ronupiwada.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸRIN LẸHIN METALỌKAN.

Adura.

OLỌRUN, alãbo gbogbo awọn ti o gbẹkẹle ọ, lẹhin ẹniti ohun kan kò li agbara, ohun kan kò ṣe mimọ́; Sọ ãnu rẹ di pipọ̀, ki o si ma bisi i lori wa; ni pe bi iwọ ti nṣe alakoso ati amọ̀na wa, ki awa ki o le ma là ohun igba diẹ kọja bẹ̃, pe nikẹhin ki awa ki o máṣe padanu ohun wọn-ni alànipẹkun: Fi eyi fu wa, Babba ọrun, nitori ti Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Rom. 8. 18.

MO ti ṣìrọ rẹ̀ pe ìya igba isisiyi kò yẹ lati fi ṣe akawe ogo ti a o fihàn ninu wa.

Digitized by Google

Nitori afojusọna ireti ti ẹda o duro dè ifihàn ti awọn ọmmọ Ọlọrun. Nitoriti a da ẹda lati foribalẹ fu asan, kì iṣe tinutinu rẹ̀, ṣugbọn nitori ẹniti o nfi ori rẹ̀ balẹ ni ireti, nitoriti a o yọ ẹda tikararẹ̀ kuro lọwọ́ idibajẹ sinu idande ti awọn ọmmọ Ọlọrun ti o li ogo. Nitoriti awa mọ̀ pe gbogbo ẹda li o nkerora ti o sì nrọbi pọ̀ titi o fi di isisiyi. Kì sì iṣe awọn nikan, ṣugbọn awa tikarawa pẹlu, ti o ni akọso Ẹmmí, ati awa tikarawa nkerora ninu ara wa, awa nduro dè isọdọmmọ, idande ti ara wa.

Ihin-rere. Luku 6. 36.

KI ẹnyin ki o li ãnu, gẹgẹ bi Babba nyin sì ti li ãnu. Ẹ máṣe dani li ẹjọ́, a kì yio sì da nyin li ẹjọ́: ẹ máṣe dani lẹbi, a kì yio sì da nyin lẹbi: ẹ darijì, a o sì darijì nyin: ẹ fi funi, a o sì fifu nyin; oṣuwọn daradara, akimọlẹ́, ati amipọ́, akún-wọ́-silẹ́, li a o wọ̀n si àiya nyin. Nitori oṣuwọn na ti ẹnyin fi wọ̀n, on li a o pada fi wọ̀n fu nyin. O sì pa owe kan fu wọn, Afọju le ṣe amọ̀na afọju? awọn mejeji kì yio ṣubu sinu ihò? Ẹniti a nkọ́ kì ijù olukọ́ rẹ̀ lọ: ṣugbọn olukuluku ẹniti o pé, yio dabi olukọ́ rẹ̀. Ẽṣe ti iwọ sì nwò ẹrún igi ti mbẹ li oju arakọnri rẹ̀, ṣugbọn iwọ kò kiyesi ìti igi ti mbẹ li oju ara rẹ̀? Tabi iwọ o ti ṣe le wi fu arakọnri rẹ pe, Arakọnri, jẹ ki emi ki o yọ ẹrún igi ti mbẹ li oju rẹ̀, nigbati iwọ tikararẹ̀ kò kiyesi ìti igi ti mbẹ li oju ara rẹ̀? Iwọ agabagebe, tète yọ ìti igi jade kuro li oju ara rẹ̀ na, nigbana ni iwọ o sì to riran gbangba lati yọ ẹrún igi kuro ti mbẹ li oju arakọnri rẹ̀.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKARUN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, fifuni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki a le fi alafia ṣe ìlana ti ipa aiye yi tobẹ lati ọdọ ijọbba rẹ wá, ki Ijọ awọn enia rẹ ki o le ma fi ayọ̀ sìn ọ ninu gbogbo ìwa-bi-Ọlọrun idakẹjẹ; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Pet. 3. 8.

KI gbogbo nyin ṣe oninu kan, ki ẹ sì ma ṣe iyọnu si ọmmọnikeji, ẹ ma fẹni bi arakọnri, ẹ ṣe iyọnu, ẹ ṣore: ẹ máṣe fi buburu san buburu, tabi fi ebú san ebú; ṣugbọn kàka bẹ ẹ fi ibukún san; ki ẹnyin ki o ma mọ̀ pe eyini li a pè nyin si, ki ẹnyin ki o le jogún ibukún. Nitori ẹniti o ba fẹ ìye, ti o sì nfẹ ri ọjọ rere, jẹ ki o pa ahọn rẹ mọ́ kuro ninu buburu, ati ète rẹ ki o má sọ̀rọ ẹtan: ki o yapa ibi silẹ, ki o sì ma ṣe rere; jẹ ki o ma wá alafia, ki o sì ma lepa rẹ̀. Nitori ti oju Oluwa mbẹ lara awọn olododo, ati etí rẹ̀ ṣí si adura wọn: ṣugbọn oju Oluwa korò si awọn ti nṣe buburu. Tani yio sì ṣe buburu si nyin, bi ẹnyin iba ṣe ọmmọ ẹhin ohun ti iṣe rere? Ṣugbọn bi ẹnyin ba jìya nitori ododo, alafia ni: ẹ máṣe fòya èru wọn, ki ẹ má sì ṣe kọn-nu; ṣugbọn ki ẹ bọ̀wọ fu Ọlọrun Oluwa li àiya nyin.

Ihin-rere. Luku 5. 1.

OSÌ ṣe, nigbati awọn enia ṣù mọ́ ọ lati gbọ́ ọ̀rọ Ọlọrun, ti o sì duro letí adagun Genesareti, O sì ri ọkọ̀ meji ti nwọn gún letí adagun: ṣugbọn awọn apẹja sọkalẹ kuro ninu wọn, nwọn ti nfọ̀ àwọn wọn. O sì wọ̀ ọkan ninu awọn ọkọ̀ na, ti ṣe ti Simon, o sì bẹ ẹ ki

Digitized by Google

o tẹ̀ si ẹ̀hin diẹ̀ kuro ni ilẹ̀. O sì joko, o sì nkọ́ awọn enia lati inu ọkọ̀ lọ. Bi o ti dakẹ̀ ọ̀rọ̀ isọ̀, o wi fu Simon pe, Tì si ibu, ki ẹnyin ki o sì jù àwọn nyin si isalẹ̀ fu akopọ̀. Simon dahùn o sì wi fu u pe, Olukọni, gbogbo oru aná li awa fi ṣiṣẹ́, awa kò sì mu nkan: ṣugbọn nitori ọ̀rọ̀ rẹ̀ emi o jù àwọn na si isalẹ̀. Nigbati nwọn sì ti ṣe eyi, nwọn kó ọ̀pọ̀ ẹja: àwọn nwọn sì ya. Nwọn sì ṣapẹ̀rẹ̀ si ẹgbẹ̀ wọn, ti o wà li ọkọ̀ ekeji, ki nwọn ki o wá lati ràn wọn lọwọ́. Nwọn sì wá, nwọn sì kún ọkọ̀ mejeji, bẽni nwọn bẹ̀rẹ̀ si irì. Nigbati Simon Peteru ri i, o wolẹ̀ lẹba ẽkun Jesu, o wipe, Lọ kuro lọdọ mi; nitori ẹlẹṣẹ̀ ni mi, Oluwa. Hà sì ṣe e, ati gbogbo awọn ti mbẹ pẹlu rẹ̀, fu akopọ̀ ẹja ti nwọn kó; bẽ sì ni Jakobu ati Johanu awọn ọmmọkọnri Sebede, ti nṣe alabapa Simon. Jesu sì wi fu Simon pe, Máṣe bẹ̀ru; lati isisiyi lọ iwọ o mu enia. Nigbati nwọn sì ti mu ọkọ̀ wọn de ilẹ̀, nwọn fi gbogbo nkan rẹ̀ silẹ̀, nwọn sì ntọ̀ ọ lẹhin lọ.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸFA LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLỌRUN iwọ ti o ti pèse irú ohun ti o kọja oyé enia lọ, fu awọn ti o fẹ ọ; Tú irú ifẹ̀ ni si ọ si wa li àiya, pe bi awa ti nfẹ ọ jù ohun gbogbo lọ, ki awa ki o le ri ileri rẹ̀ gbà, ti o ta ohun gbogbo yọ ti awa le fẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Rom. 6. 3.

ENYIN kò mọ̀ pe, iye awọn ninu wa ti a baptisi sinu Jesu Kristi, a baptisi wọn

Digitized by Google

sinu ikú rẹ̀? Njẹ a sì fi baptismu sin wa pọ̀ pẹlu rẹ̀ sinu ikú: pe gẹgẹ bi a ti jí Kristi Jesu dide kuro ninu okú nipa ogo ti Babba, gẹgẹ bẹ̃li o yẹ ki awa ki o ma rìn li ọ̀tun ìwa. Njẹ bi o ba ṣepe a gbìn wa pọ̀ ninu afarawe ti ikú rẹ̀, awa o sì ri bi afarawe ti ajinde rẹ̀: eyi li awa sì nmọ̀ pe, a kàn ogbologbo ọkọnri wa mọ agbelebu pẹlu rẹ̀, ki a le pa ara ẹ̀ṣẹ̀ kú, lati isisiyi lọ ki a má le sìn ẹ̀ṣẹ̀ mọ́. Nitori ẹniti o kú, o bọ lọwọ́ ẹ̀ṣẹ̀. Njẹ bi awa ba bá Kristi kú, awa gbagbọ́ pe awa o sì wà lãye pẹlu rẹ̀: awa mọ̀ pe bi a ti jí Kristi dide kuro ninu okú, kò ni ikú mọ́; ikú kò le ṣe oluwa rẹ̀ mọ́. Nitoriti ti o kú, o di okú si ẹ̀ṣẹ̀ lẹ̃kan: nitoriti ti o sì wà lãye, o wà lãye si Ọlọrun. Bẹ̃ni gẹgẹ ki ẹnyin ki o kà ara nyin di okú nitõtọ̀ si ẹ̀ṣẹ̀, ṣugbọn ẹnyin wà lãye si Ọlọrun nitori Jesu Kristi Oluwa wa.

Ihin-rere. Mat. 5. 20.

JESU wi fu ọmmọ̀ ẹhin rẹ̀ pe, Bikoṣepe ododo nyin ba koja ododo awọn akọwe pẹlu ti awọn Farisi, ẹnyin kì yio le de ijọ̀bba ọrun bi o ti wù ki o ri. Ẹnyin ti gbọ́ bi a ti wi fu awọn ara igbani pe, Iwọ kò gbọdọ̀ pania; ẹnikẹni ti o ba pania yio wà li ewu idajọ̀. Ṣugbọn emi wi fu nyin, Ẹnikẹni ti o binu si arakọnri rẹ̀ lasan, yio wà li ewu idajọ̀; ati ẹnikẹni ti o ba wi fu arakọnri rẹ̀ pe, Raka, yio wà li ewu ti ijọ̀ awọn igbimọ̀; ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba wipe, Iwọ aṣiwere, yio wà li ewu ti iná ajõku ọrun apadi. Nitorina bi iwọ̀ ba nmu ẹ̀bun rẹ̀ wá si ibi pẹpẹ, bi iwọ̀ ba ranti pe, arakọnri rẹ̀ li ohun kan ninu si ọ̀; fi ẹ̀bun rẹ̀ silẹ̀ nibẹ̀ niwaju pẹpẹ, pada lọ sile; tète ba arakọnri rẹ̀ làja na, nigbana ni ki o to wá ibun ẹ̀bun rẹ̀. Ba ọ̀tá rẹ̀ ré kánkan,

Digitized by Google

nigbati iwọ wà li ọna pẹlu rẹ; li akokò eyi ki ọtá rẹ ki o má ba fi ọ le onidajọ lọwọ́, onidajọ a sì fi ọ le tẹtu lọwọ́, a sì gbé ọ sọ sinu tubu. Lõtọ ni mo wi fu ọ, Iwọ kì yio jade kuro nibẹ̀, titi iwọ o fi san owo kan iyokù.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKEJE LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, ti agbara ati ipa gbogbo, iwọ ẹniti ṣe olorisọn ati olufuni li ohun didara gbogbo; Lọ́ ifẹ́ Orukọ rẹ si wa li àiya, mu ìsin Ọlọrun ti o tọ́ ki o ma bisi ninu wa, ma fi ore rẹ gbogbo bọ́ wa, ati ninu ãnu rẹ nla pa wa mọ́ ninu rẹ̀ na; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Rom. 6. 19.

EMI nsọ̀rọ yi bi ède enia nitori àllera ara nyin: nitori bi ẹnyin ti jọwọ ẹ̀ya ara nyin lọwọ́ li ọmmọ ọdọ fu ẽri ati sinu ẹ̀ṣẹ̀ de ẹ̀ṣẹ̀; bẽni ki ẹnyin ki o sì jọwọ ẹ̀ya ara nyin lọwọ́ li ọmmọ ọdọ si ododo si mimọ́ ìwa. Nitori igbati ẹnyin ti nṣe ọmmọ ọdọ ẹ̀ṣẹ̀, ẹnyin ti bọ lọwọ́ ododo. Njẹ ère kili ẹnyin ha jẹ ninu ohun ti oju ntì nyin si nisisiyi? nitori ikú li opin nkan wọn-ni. Ṣugbọn nisisiyi ti a mu nyin yọ kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀, ti ẹnyin si di ọmmọ ọdọ Ọlọrun, ẹnyin njẹ ère nyin si mimọ́ ìwa, ati opin rẹ ìye ti kò nipẹkun. Nitori ikú li ère ẹ̀ṣẹ̀; ṣugbọn ẹ̀bun ọfẹ ti Ọlọrun ni ìye ti kò nipẹkun nitori Jesu Kristi Oluwa wa.

Ihin-rere. Marku 8. 1.

LI ọjọ wọn-ni nigbati ijọ awọn enia pọ̀ gidigidi, ti nwọn kò sì li onjẹ, Jesu pè awọn

Digitized by Google

ọmmọ ẹhin rẹ̀ sọdọ rẹ̀, o sì wi fu wọn pe, Ánu ijọ awọn enia nṣe mi, nitoriti o di ijọ mẹta nisisiyi ti nwọn ti wà lọdọ mi, nwọn kò sì li ohun ti nwọn yio jẹ: bi emi ba sì rán wọn lọ si ile wọn li ebi, ãrẹ̀ yio mu wọn li ọna: nitoriti awọn pipọ li o ti ọna jijìn wá. Awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ sì da a lohùn wipe, Nibo li a o gbé ti fi akara tẹ́ awọn enia yi lọrùn li aginjù yi? O sì bi wọn lẽre, wipe, Iṣu akara melo li ẹnyin ni? Nwọn sì wipe, Meje. O sì ni ki a mu awọn enia joko ni ilẹ: o sì mu iṣu akara meje na, o sure, o bu u, o sì fifu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀, ki nwọn ki o gbé e kalẹ niwaju wọn; nwọn sì gbé e kalẹ niwaju awọn enia. Nwọn sì li ẹja kekere diẹ: o sì sure, o sì ni ki a fi wọn siwaju wọn pẹlu. Bẹ̃ni nwọn jẹ, nwọn sì yó: nwọn sì kó ajẹkù ti o kù jọ agbọn meje kún. Awọn ti o jẹ ẹ to ìwọn ẹgbaji enia: o sì rán wọn lọ.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸJỌ LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLỌRUN, lai ìpese ẹniti kì itase ti o ṣe ìlana ohun gbogbo ati li ọrun, ati lori ilẹ; Awa nfi irẹlẹ ohùn bẹ̀bẹ lọdọ rẹ lati mu ohun gbogbo ti ipani-lara kuro lọdọ wa, ki o sì fu wa li ohun nwọn-ni ti o ṣe anfani fu wa; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Rom. 8. 12.

ARAKỌNRI, ajigbese li awa, ki iṣe ti ara, ti a o fi wà ni ipa ti ara. Nitori bi ẹnyin ba wà ni ipa ti ara, ẹnyin o kú: ṣugbọn nipa ti Ẹmmí bi ẹnyin ba npọn iṣe ti ara loju,

Digitized by Google

ẹnyin o yè. Nitori iye awọn ti a nṣe amọ̀na fu lati ọdọ Ẹmmí Olọrun wá, awọn ni iṣe ọmmọ Olọrun. Nitori ẹnyin kò gbà ẹmmí ìdeni lati bẹ̀ru mọ́; ṣugbọn ẹnyin ti gbà Ẹmmí isọdọmmọ, nipa eyi ti awa fi nkepè, Aba, Babba. Ẹmmí tikararẹ̀ li o njẹ́ ẹmmí wa li ẹrí pe, ọmmọ Olọrun li awa ṣe: bi awa iba ṣe ọmmọ, njẹ awa li ajogun; ajogun ti Olọrun, ati ajumọ-jogun pẹlu Kristi; bi o ba ṣepe awa bá a jìya, ki a le ṣe wa logo pẹlu rẹ̀.

Ihin-rere. Mat. 7. 15.

EMA kiyesi awọn eke woli ti o ntọ̀ nyin wá li awọ agutan, ṣugbọn apanijẹ ikorikò ni nwọn ninu. Eso wọn li ẹnyin o fi mọ̀ wọn. Enia a ma ká eso ajara lori ẹgún ọgán, tabi a ma ká eso ọpọtọ ninu ẹ̀wọn? Gẹgẹ bẹ̃ gbogbo igi rere ni so eso rere; ṣugbọn igi buburu ni sì so eso buburu. Igi rere kò le so eso buburu, bẹ̃ni igi buburu kò sì le so eso rere. Gbogbo igi ti kò ba so eso rere, a ke e lùlẹ, a sì wọ́ ọ sọ sinu iná. Nitorina nipa eso wọn li ẹnyin yio fi mọ̀ wọn. Kì iṣe gbogbo ẹniti npè mi li Oluwa, Oluwa, ni yio wọ̀le ijọba ọrun; bikoṣe ẹniti nṣe ifẹ́ ti Babba mi ti mbẹ li ọrun.

ỌJỌ́ ỌLỌRUN ẸKẸSAN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, fifu wa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, li ẹmmí ati ma rò on ati ma ṣe irú ohun nwọn-ni ti o tọ́ nigba-gbogbo; pe awa, ti kò le ṣe ohun kan ti o dara lẹhin rẹ, nipasẹ rẹ ki a le kún wa lọwọ́ lati ma gbé ìwa gẹgẹ bi ifẹ́ rẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. 1 Kor. 10. 1.

ARAKỌNRI, emi kò fẹ ki ẹnyin ki o ṣe alaìmọ, bi gbogbo awọn babba wa ti mbẹ labbẹ awọ sanma, ti gbogbo wọn sì là okun já; ti a sì baptisi gbogbo wọn si Mose ninu awọ sanma ati ninu okun; ti gbogbo wọn sì ti jẹ onjẹ ẹmmí kan na; ti gbogbo wọn sì ti mu ohun mimu ẹmmí kan na: nitoripe nwọn nmu ninu Apatta ẹmmí ni ti ntọ wọn lẹhin: Kristi sì li Apatta na. Ṣugbọn ọpọlọpọ wọn ni inu Ọlọrun kò dùn si: nitoripe a bì wọn ṣubu li aginjù. Gbogbo nkan wọnyi si jasi apẹrẹ fu wa nisisiyi, nikẹhin ki awa ki o máṣe ṣe ifẹkufẹ si ohun buburu, gẹgẹ bi awọn pẹlu ti ṣe ifẹkufẹ. Bẹ̀ni ki ẹnyin ki o má sì ṣe abọrisa, bi awọn omiran ti ṣe ninu wọn; gẹgẹ bi a ti kọ ọ wipe, Awọn enia na, joko lati ma jẹ ati lati ma mu, nwọn sì dide soke lati ma ṣire. Bẹ̀ni ki awa ki o má sì ṣe àgbere bi awọn ẹlomiran ti ṣe, ti ẹgba mọkanla le ẹgbẹrun enia ṣubu ni ijọ kan ninu wọn. Bẹ̀ni ki awa ki o máṣe dan Kristi wò, gẹgẹ bi awọn ẹlomiran pẹlu ninu wọn ti dan a wò, ti a sì fi ejò run wọn. Bẹ̀ni ki ẹnyin ki o máṣe kù ninu nyin, gẹgẹ bi awọn ẹlomiran pẹlu ninu wọn ti kù, a sì run wọn lati ọwọ oluparun ni wá. Gbogbo nkan wọnyi ti o ṣẹ si wọn sì jasi apẹrẹ fu wa: a sì kọwe wọn lati jẹ ikilọ fu wa, lori ẹniti igbẹhin aiye mbọ wá si. Nitorina ẹnikẹni ti o ba rò pe on duro, ki o kiyesi ara, ki o má ba ṣubu. Kò sá ti isi idanwò kan ti o ti bá nyin, bikoṣe irú eyiti o mọ niwọn fu enia: ṣugbọn olododo li Ọlọrun, ẹniti kì yio jẹ ki a dan nyin wò jù bi ẹnyin ti le gbà; ṣugbọn on o ṣe ìlana kan pẹlu ninu idanwò na lati là, ki ẹnyin ki o le gbà a.

Digitized by Google

ADURA.

Ihin-rere. Luku 16. 1.

OSÌ wi fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ pe, Ọkọnri kan ọlọrọ̀ ti wà, ti o ni iriju kan; on na ni nwọn fi sùn u pe, o ti nfi ọrọ̀ rẹ̀ ṣòfo. Nigbati o sì pè e, o wi fu u pe, Ẹṣe ti emi fi ngbọ́ eyi nitori rẹ? ṣìro iṣẹ iriju rẹ; nitori bọya iwọ kì yio ṣe iriju pẹ mọ́. Iriju na sì wi ninu ara rẹ̀ pe, Ewo li emi o ṣe? nitoriti Oluwa mi gbà iṣẹ iriju lọwọ́ mi: emi kò le wàlẹ; lati ṣagbe oju ntì mi. Mo mọ̀ bi emi o ti ṣe, nigbati a ba mu mi kuro nibi iṣẹ iriju, ki nwọn ki o le gbà mi sinu ile wọn. Bẹ̌li o sì pè olukuluku awọn ajigbese ti oluwa rẹ̀ ṣọdọ rẹ̀, o sì bi ekini pe, Elo ni iwọ jẹ oluwa mi? O sì wipe, Ọgọrun oṣuwọn oróro. O sì wi fu u pe, Mu iwe rẹ, ki iwọ ki o sì joko nisisiyi, ki iwọ ki o kọwe ti adọta. Nigbana li o sì bi ẹnikeji pe, Elo ni iwọ jẹ? On sì wipe, Ọgọrun oṣuwọn alikama. O sì wi fu u pe, Mu iwe rẹ, ki iwọ ki o kọwe ti ọgọrin. Oluwa sì yìn alaìṣõtọ iriju na, nitoriti o fi ọgbọ́n ṣe e: awọn ọmmọ aiye yi sá gbọ́n ni iran wọn jù awọn ọmmọ imọlẹ lọ. Ki emi ki o wi fu nyin, ẹ fi mamon alaìṣõtọ yàn ọrẹ́ fu ara nyin; nigbati ẹnyin ba yẹ̀, ki nwọn ki o le gbà nyin si ibujoko wọn titi aiye.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸWA IẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, jẹ ki etí ãnu rẹ ki o ṣí si adura awọn iranṣẹ rẹ onirẹlẹ ohùn; ati ki nwọn ki o le ri ìbere wọn gbà, mu wọn bère irú ohun ti yio ma wù ọ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. 1 Kor. 12. 1.

ARAKỌNRI, emi kò fẹ ki ẹnyin ki o wà li ọ̀pe nipa ti ẹ̀bun ẹmmí. Ẹnyin sá mọ̀ bi ẹnyin ti jẹ Keferi ti a fà lọ sọdọ odi orisa wọnyi, gẹgẹ bi a ti dari nyin. Nitorina mo wi fu nyin lati mọ̀ pe, kò si ẹnikẹni ti nsọ̀rọ nipa Ẹmmí Ọlọrun, ti o le pè Jesu li ẹni ifibu: ati pe, kò si ẹniti o le wipe, Oluwa ni Jesu iṣe, bikoṣe nipa Ẹmmí Mimọ́. Nisisiyi onirũru ẹ̀bun li o sá wà, ṣugbọn ọkan li Ẹmmí. Ati onirũru iṣẹ alufa li o sì wà, ṣugbọn Oluwa kan na ni. Ati alarabara iṣẹ li o sì wà, ṣugbọn Ọlọrun kan na ni nṣiṣẹ gbogbo wọn ninu gbogbo wọn. Ṣugbọn a nfi ifihàn ti Ẹmmí fu olukuluku enia lati jère nipasẹ rẹ̀. Nitoriti a fi ọ̀rọ ọgbọ́n fu ẹnikan nipa ti Ẹmmí; ati fu ẹlomiran ọ̀rọ ìmọ nipa Ẹmmí kan na; ati fu ẹlomiran igbagbọ́ nipa Ẹmmí kan na; ati fu ẹlomiran ẹ̀bun imularada nipa Ẹmmí kan na; fu ẹlomiran iṣẹ iyanu iṣe; fu ẹlomiran isọtẹlẹ; fu ẹlomiran ìmọ ẹmmí; fu ẹlomiran onirũru èdè ifọ̀; fu ẹlomiran itumọ̀ èdè: ṣugbọn gbogbo wọnyi li ẹnikan ni, ani Ẹmmí kan na nṣe, o npín fu olukuluku gẹgẹ bi o ti wù u.

Ihin-rere. Luku 19. 41.

NIGBATI o sì sumọ́ etile, o ṣijuwò ilu nla na, o sọkun si i lori, O nwipe, Iba ṣepe iwọ mọ̀, iwọ na, loni ọjọ rẹ, ohun ti ṣe alafia rẹ! ṣugbọn nisisiyi nwọn pamọ́ kuro li oju rẹ. Nitori ọjọ mbọ̀ fu ọ, ti awọn ọtá rẹ yio wà yàra ká ọ, nwọn o sì yi ọ ká, nwọn o sì saga tì ọ niha gbogbo, nwọn o sì wó ọ palẹ bẹrẹ, ati awọn ọmmọ rẹ ninu rẹ; nwọn kì yio sì fi okuta kan silẹ lori ara wọn; nitoriti

Digitized by Google

iwọ kò mọ ọjọ ìbẹwo rẹ. O sì wọ inu tempeli (ile Ọlọrun) lọ, o sì bẹrẹ si ilé awọn ti ntà ati awọn ti nrà ninu rẹ sode; O wi fu wọn pe, A kọwe rẹ pe, Ile adura ni ile mi; ṣugbọn ẹnyin ti sọ ọ di ihò olè.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKỌKANLA LẸHIN METALỌKAN.

Adura.

OLỌRUN, iwọ ti o fi ipá rẹ gbogbo hàn li ọ̀pọ̀lọpọ ni ṣiṣe ãnu ati iyọnu; Fi ãnu fi irú ọ̀ṣuwọn ore-ọfẹ rẹ ni fu wa, ki awa, ti nsúre nipa ọ̀na ofin rẹ, ki a le ri ileri rẹ oninu ore-ọfẹ gbà, ki a sì sọ wa di alabapin ti iṣura rẹ ọrun; nitori Jesu Kristi Oluwa. *Amin.*

Episteli. 1 Kor. 15. 1.

ARAKỌNRI, emi nrò hin lhin rere na fu nyin ti mo ti nwasu fu nyin, eyiti ẹnyin pẹlu sì ti gbà, ninu eyi ti ẹnyin sì duro; nipasẹ eyiti a o fi gbà nyin là pẹlu, bi ẹnyin ba di ọ̀rọ ti mo ti nwasu fu nyin mu ṣinṣin, bikoṣepe ẹnyin ba gbagbọ́ lasan. Nitoripe siwaju ohun gbogbo mo fi eyiti mo ti gbà le nyin lọwọ́ pẹlu, bi Kristi ti kú nitori ẹ̀ṣẹ wa gẹgẹ bi iwe mimọ́ Ọlọrun ti wi; ati pe a sinkú rẹ, ati pe o tún jinde ni ijọ ẹkẹta gẹgẹ bi iwe mimọ́ Ọlọrun ti wi: ati pe a ri i lati ọdọ Kefa, lẹhin eyini a sì ri i lọdọ awọn mejejila: lẹhin eyini a ri i lẽkan ṣoṣo lọdọ awọn arakọnri ti o jũ ẹdẹgbẹta lọ; apakan ti o pọ̀ju ninu wọn wà titi fi di isisiyi, ṣugbọn awọn diẹ ti dubulẹ sùn. Lẹhin eyini a ri i lọdọ

Digitized by Google

gbogbo awọn Aposteli. Ati nikẹhin gbogbo wọn a ri i lọdọ mi pẹlu, bi ẹnikan ti a bí li ọmmọ iṣẹnu siwaju igba akokò rẹ. Nitori emi li ẹniti o kere jùlọ ninu awọn Aposteli, ti emi kò yẹ li ẹniti a ba pè li Aposteli kan, nitoriti mo ti nṣe inunibini si ijọ awọn enia Ọlọrun. Ṣugbọn nipa ore-ọfẹ Ọlọrun, mo jasi ohun ti mo jasi: ati ore-ọfẹ rẹ ti a fifu mi kò sì jẹ asan; ṣugbọn mo ṣiṣẹ lọpọlọpọ jù gbogbo wọn lọ: ṣugbọn kì iṣe emi, bikoṣe ore-ọfẹ Ọlọrun ti o wà pẹlu mi. Nitorina iba ṣe emi tabi awọn ni, bẽli awa nwasu, bẽ ẹnyin sì ngbagbọ́.

Ihin-rere. Luku 18. 9.

JESU sì pa owe yi fu awọn kan ti nwọn gbẹ kẹle ara wọn pe, awọn li olododo, ti nwọn sì ngàn awọn ẹlomiran: pe, Awọn ọkọnri meji lọ si ile Ọlọrun (tempeli) lati ma gbadura; ọkan a ma ṣe Farisi, eyi ekeji a ma ṣe agbowode. Nigbati eyi Farisi dide, o ngbadura ninu ara rẹ wi bayi pe, Ọlọrun, mo dupẹ lọwọ́ rẹ, nitori ti emi kò ri bi ara iyokun, awọn alọnilọwọgba, alalṣõtọ, panṣaga, tabi emi kò tilẹ ri bi agbowode yi. Emi gbàwẹ li ẹrinmeji li ọsẹ, mo san idamẹwa ohun gbogbo ti mo ni. Agbowode sì duro li òkere, kò tilẹ jẹ gbé oju rẹ soke ọrun, o sì lù ara rẹ li owokan àiya, o wipe, Ọlọrun ṣãnu fu mi ẹlẹṣẹ. Mo wi fu nyin, ọkọnri yi sọkalẹ si ile rẹ ni idalare jù ekeji lọ: nitori ẹnikẹni ti o ba gbé ara rẹ ga on li a o rẹ silẹ; ẹniti o ba sì rẹ ara rẹ silẹ on li a o gbéga soke.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN EKEJILA LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, iwọ ti o mura nigba-gbogbo lati gbọ́ jù wa lọ lati gbà adura, ti o sì fẹ lati funi jù bi awa ti fẹ, ati bi o sì ti yẹ fu wa lọ; Tú ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ ãnu rẹ si wa lori; ma dari ohun wọn-ni jì wa ti ọkkàn wa mbẹ̀ru, ki o sì ma fi ohun rere wọn-ni fu wa ti awa kò yẹ lati bère, bikoṣe nitori itoye ati ìlaja Jesu Kristi, Ọmmọ rẹ, Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 2 Kor. 3. 4.

IRÚ igbẹkẹle yi li awa ni nipa Kristi ṣọdọ Ọlọrun: kì iṣe pe awa to fu ara wa lati ṣe ìro ohunkohun bi ẹnipe ti awa tikarawa; ṣugbọn Ọlọrun ni tito wa; ẹniti o sì ti fi wa ṣe alufa ti majẹmu titun ti o pé; kì iṣe ti iwe, bikoṣe ti ẹmmí: nitori ti iwe a ma pani, ṣugbọn ẹmmí a ma ṣọni di ãye. Ṣugbọn bi iṣẹ́ alufa ti ikú, ti a ti kọwe rẹ̀, ti a sì ti ṣe ọ̀nà finfin rẹ̀ si ara okuta, ba jẹ ologo, tobẹ̃ ti awọn ọmmọ Israeli kò le tẹjumọ lati wò oju Mose, nitori ogo oju rẹ̀; ogo ti a o ṣọ di asan: yio ha ti ri ti iṣẹ́ alufa ti ẹmmí kì yio kuku jẹ ologo julọ? Nitoripe bi iṣẹ́ alufa fu idalẹbi ba jẹ ologo, melomelo ni iṣẹ́ alufa ododo yio rekọja li ogo.

Ihin-rere. Marku 7. 31.

JESU kuro li àgbegbe Tire on Sidon, o wá si adagun Galili larin àgbegbe Dekapoli. Nwọn sì mu enia kan wá ṣọdọ rẹ̀ ti etí rẹ̀ dì, o sì yadi li ahọn rẹ̀; nwọn sì bẹ̀ ẹ pe, ki o gbé ọwọ́ rẹ̀ le e. O sì mu u kuro larin ijọ

Digitized by Google

awọn enia lọ si apakan, o sì tẹ ika rẹ̀ bọ̀ ọ li etí, nigbati o tutọ́, o sì fi ọwọ́ tọ́ o li ahọn; O sì gbé oju soke wò ọrun, o kẹdọ̀n, o sì wi fu u pe, Efata, eyini ni, Iwọ ṣí. Lojukan na, etí rẹ̀ si ṣí, okùn ahọn rẹ̀ sì tú, o sì nfọhun kerekere. O sì kìlọ fu wọn pe, ki nwọn ki o máṣe sọ fu ẹnikẹni: ṣugbọn bi o ti nkìlọ fu wọn to, bẽ̀ gẹ̀gẹ̀ ni nwọn sì nkokikí rẹ̀; ẹnu si yà wọn gidigidi rekọja, nwọn wipe, O ṣe ohun gbogbo dara: o mu ki aditi gbọran, o sì mu ki odi fọhun.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸTALA LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLODUMARE ati Ọlọrun alãnu, lati kìki inu ẹ̀bun ẹniti o ti wá, ti awọn enia rẹ̀ olõtọ́ fi iṣe ìsin otitọ́ ati ti iyìn si ọ. Fifuni, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ̀ rẹ̀, ki awa ki o le ma sìn ọ nitõtọ́ tobẽ̀ li aiye yi, ki awa ki o máṣe tase nigbẹ̀hin lati ri awọn ileri rẹ̀ ọrun gbà; nipasẹ̀ itoye Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Gal. 3. 16.

FU Abrahamu ati fu irú ọmmọ̀ rẹ̀ kan li a ti ṣe ileri wọn-ni. On kò wipe, Fu awọn irú ọmmọ̀, bi ẹnipe ọ̀pọ̀lọpọ̀; ṣugbọn bi ẹnipe ọkan, Ati fu irú ọmmọ̀ rẹ̀, eyiti iṣe Kristi. Eyi ni emi nwipe, majẹmu ni, ti Ọlọrun ti muṣẹ̀ niṣaju, nipasẹ̀ Kristi, ani ofin ti o de lẹhin ọgbọ̀n le nirinwo ọdún kò le sọ ọ dasan, ti a ba fi mu ileri na tase. Nitoripe bi ọrọ̀ ilẹnini na ba ṣe nipa ti ofin, kì iṣe nipa ti ileri mọ́: ṣugbọn Ọlọrun ti fi i fu Abrahamu nipa ileri. Njẹ̀ ìsin kili ofin ha jasi? A fi

Digitized by Google

ofin kún u nitori ẹ̀ṣẹ́, titi irú ọmmọ ti a ti ṣe ileri fu yio fi de; a sì ti ipasẹ̀ awọn angeli ṣe ìlana rẹ̀ lati ọwọ́ onilaja kan wá. Njẹ onilaja kì iṣe onilaja ti ẹnikan, ṣugbọn ọkan li Ọlọrun. Nitorina ofin ha nṣe ìdena si ileri Ọlọrun bi? Ki a má ri i: nitori iba ṣepe ofin kan ti wà ti a fi funi, ti o le fi ìye funi, nitõtọ ododo iba ti ipasẹ̀ ofin wá. Ṣugbọn Iwe mimọ́ Ọlọrun ti há gbogbo wọn mọ́ sabbẹ ẹ̀ṣẹ́, ki a le fi ileri nipa igbagbọ́ Jesu Kristi fu awọn ti o gbagbọ́.

Ihin-rere. Luku 10. 23.

IBUKÚN ni fu oju ti nri ohun ti ẹnyin nri: nitori mo wi fu nyin, Woli ati ọbba pipọ li o nfẹ lati ri ohun ti ẹnyin nri, nwọn kò sì ri wọn; ati lati gbọ́ ohun ti ẹnyin ngbọ́, nwọn kò sì gbọ́ wọn. Sá sì kiyesi i, amofin kan dide, o ndan a wò, o ni, Olukọni, kili emi iba ṣe ki emi ki o le jogún aiye alnipẹkun? O sì bi i pe, Kili a kọ sinu iwe ofin? bi iwọ ti kà a? O sì dahùn wipe, Ki iwọ ki o fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkkàn rẹ, ati gbogbo agbara rẹ, ati gbogbo inu rẹ, fẹ Oluwa Ọlọrun rẹ; ati ẹnikeji rẹ bi ara rẹ. O sì wi fu u pe, Iwọ dahùn rere: ṣe eyiyi, iwọ o sì yè. Ṣugbọn o nfẹ lati yìn ara rẹ̀, o wi fu Jesu pe, Tani ha li ẹnikeji mi? Jesu sì dahùn o wipe, Ọkọnri kan nti Jerusalemu sọkalẹ lọ si Jeriko, o sì bọ si ọwọ́ awọn olè, ti nwọn gbà a li aṣọ, nwọn ṣá a lọgbẹ, nwọn sì fi i silẹ lọ li alpa li apatan. Ni alabapade li alufa kan nsọkalẹ lọ niha ibẹ̀: nigbati o sì ri i, o kọja lọ niha ekeji. Ati Lefite kan pẹlu, nigbati o de ibẹ̀, o wá, o wò o, o sì kọja lọ niha ekeji. Ṣugbọn ara Samaria kan, bi o ti nrè àjo, o de ibi ti o gbé wà: nigbati o sì ri i, ãnu ṣe e, O sì tọ ọ

Digitized by Google

lọ, o sì dì i lọgbẹ, o da oróro on ọti wain si i, o sì gbé e le ori ẹranko rẹ ti o ngùn, o sì mu u wá si ile èro, o sì nṣe itọju rẹ. Nigbati o sì lọ ni ijọ ekeji, o fi owo idẹ meji fu bãle èro, o sì wi fu u pe, Ma tọju rẹ; ohunkohun ti iwọ ba sì ná si i, nigbati mo ba pada de, emi o san a fu ọ. Ninu awọn mẹtẹta wọnyi, tani iwọ ṣebi ṣe ẹnikeji ẹniti o bọ si ọwọ awọn olè? O sì dahùn wipe, Ẹniti o ṣãnu fu u. Nigbana ni Jesu sì wi fu u pe, Lọ, ki iwọ ki o sì ṣe bẽ gẹgẹ.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸRINLA LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, fi ibisi igbagbọ́, ireti, ati ifẹni fu wa; ati ki awa ki o le ri ohun ti iwọ ṣe ileri gbà, mu wa ki a fẹ eyi ti iwọ pa li aṣẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Gal. 5. 16.

NJẸ mo ni, Ẹ ma rìn nipa ti Ẹmmí, ki ẹ má sì ṣe mu ifẹkufẹ ti ara ṣẹ. Nitoriti ara nṣe ifẹkufẹ lodi si Ẹmmí, ati Ẹmmí lodi si ara: awọn wọnyi sì yàtọ si ara wọn, ekini si ekeji: bẽli ẹnyin kò le ṣe ohun ti ẹnyin nfẹ Ṣugbọn bi a ba nṣe amọ̀na nyin lati ọdọ Ẹmmí wá, ẹnyin kò si labbẹ ofin. Njẹ awọn iṣẹ ti ara farahàn nisisiyi, ti iṣe nwọnyi; Panṣaga, àgbere, ìwa-ẽri, wọ̀bia, ibọrisa, oṣó, irira, lja, ilara, ibinu, asọ, lṣọtẹ, adamọ̀, arankàn, ipania, imọtipara, aiye ajẹju, ati irú wọn-ni: awọn ti mo ti nsọ fu nyin ṣaju, gẹgẹ bi mo sì ti sọ fu nyin tẹlẹ ri pe, awọn ti nṣe nkan ba wọn-ni kì yio jogún ijọbba Ọlọrun. Ṣugbọn

Digitized by Google

awọn eso ti Ẹmmí ni ifẹ́, ayọ̀, alafia, ipamọra, ìwa pẹlẹ, iṣore, igbagbọ́, ìwa tutù, ati alarekọja: ofinkofin kò lodi si irú wọn-ni. Awọn ti iṣe Kristi ti kàn ẹran ara mọ agbelebu pẹlu ifẹ́ ọkkàn ati ifẹkufẹ ara rẹ̀.

Ihin-rere. Luku 17. 11.

OSÌ ṣe, nigbati o nlọ si Jerusalemu, o kọja lọ larin Samaria on Galili. Bi o sì ti nwọ̀ inu iletò kan lọ, awọn ọkọnri adẹtẹ̀ mẹwa pade rẹ̀, nwọn duro li òkere: nwọn sì nahùn soke, wipe, Jesu, Babba, ṣãnu fu wa. Nigbati o ri wọn, o wi fu wọn pe, Ẹ lọ ẹ fi ara nyin hàn fu awọn alufa. O sì ṣe, bi nwọn ti nlọ, nwọn sì di mimọ́. Nigbati ọkan ninu wọn ri pe on di mimọ́, o pada sẹhin, o sì fi ohùn rara yìn Ọlọrun logo, o sì wolẹ lẹba ẹsẹ rẹ̀, o ndupẹ fu u: ara Samaria ni sì iṣe. Jesu sì dahùn wipe, Awọn mẹwa ki a sọdi mimọ́? Awọn mẹsan iyokun ha wà? A kò ri ẹnikan ti o pada wá fi iyìn fu Ọlọrun, bikoṣe alejò yi? O sì wi fu u pe, Dide, ma ba ti rẹ lọ: igbagbọ́ rẹ mu ọ lara da.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸDỌGUN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, pa Ijọ awọn enia rẹ mọ́ ninu ãnu rẹ titi: ati nitori ti àllera ti enia, lẹhin rẹ awa kọ le ṣe àlṣubu, nipa iranlọwọ rẹ pa wa mọ́ lai kuro ninu ohun ipani-lara gbogbo, ki o sì ṣe amọna wa si ohun gbogbo ti o ṣe anfani si igbala wa; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. Gal. 6. 11.

ẸNYIN ri bi mo ti fi ǫwǫ́ emi tikarami kǫ iwe nla kan si nyin. Iye awǫn ti nfẹ ṣe ifihàn rere li ara, nwǫn nrǫ́ nyin lati kǫla; nitori ki nwǫn ki o máṣe jìya inunibini nitori agbelebu Kristi. Nitori awǫn ti a kǫ-nilà papa kò pa ofin mǫ́, ṣugbǫn nwǫn nfẹ mu nyin kǫla, ki nwǫn ki o le ma ṣogo lori ara nyin. Ṣugbǫn ki a máṣe ri pe emi nṣogo, bikoṣe ninu agbelebu Jesu Kristi Oluwa wa, nipaṣẹ ẹniti a ti kàn aiye mǫ́ agbelebu fu mi, ati emi fu aiye. Nitoripe ninu Kristi Jesu ikǫla kò di ohunkohun, tabi aìkola, bikoṣe ẹda titun. Iye awǫn ti o sì nrìn gẹgẹ bi ìwǫn yi, alafia lori wǫn, ati ãnu, ati lori awǫn Israeli Ọlọrun. Lati isisiyi lọ, ki ẹnikẹni máṣe yọ mi lẹnu mǫ́: nitoriti emi nrù apá Jesu Oluwa kiri li ara mi. Arakǫnri, ore-ǫfẹ Jesu Kristi Oluwa wa, ki o wà pẹlu ẹmmí nyin. Amin.

Ihin-rere. Mat. 6. 24.

KÒ si ẹniti o le sìn oluwa meji: bikoṣepe o korira ǫkan, ki o sì fẹ ekeji; bi kò sì ṣe bẽ yio faramǫ́ ǫkan, yio sì yàn ekeji ni ipǫsi. Ẹnyin kò le sìn Oluwa pẹlu mamon. Nitorina mo wi fu nyin, Ẹ máṣe gbèro nitori ẹmmí nyin pe, kili ẹ o jẹ, tabi kili ẹ o mu; ati fu ara nyin pe, kili ẹ o fi bora. Ẹmmí kò jù onjẹ lọ? tabi ara ni kò jù aṣọ lọ? Ẹ sá wò ẹiyẹ oju ǫrun; nwǫn kò fǫn irugbin, bẽni nwǫn kò ká, nwǫn kì sì kójọ sinu abà, ṣugbǫn Babba nyin ti mbẹ li ǫrun mbǫ́ wǫn. Ẹnyin kò ha sian jù wǫn lọ? Tani ninu nyin ti o le fi ìgbero fi igbǫnwọ kan kún giga rẹ? Nitori kili ẹnyin sì ṣe ngbèro aṣọ? Kiyesi lili ti mbẹ ni igbẹ́ bi nwǫn ti ndàgba; nwǫn kò ṣiṣẹ, bẽni nwǫn kò ranwu: mo sì wi fu nyin

Digitized by Google

pe, A kò ṣe Solomon papa li ọṣọ ninu gbogbo ogo rẹ to bi ọkan ninu wọnyi. Njẹ bi Olọrun ba wọ̀ koriko igbẹ́ li aṣọ tobẹ̃ ti o wà loni, ti a sì gba a sinu iná lọla, melomelo ni kì yio fi le wọ̀ nyin li aṣọ, Ẹnyin oni-kekere igbagbọ́? Nitorina ẹ má gbèro, wipe, Kili a o jẹ? tabi, Kili a o mu? tabi, Nibo li a o ti fi aṣọ wọ̀ wa? Nitori gbogbo nkan wọnyi li awọn keferi nwá kiri. Babba nyin ti mbẹ li ọrun mọ̀ pe, ẹnyin kò le ṣe alaìni gbogbo nkan wọnyi. Ṣugbọn ẹ tète ma wá ijọbba Olọrun na, ati ododo rẹ̀; gbogbo nkan wọnyi li a o sì fi kún u fu nyin. Nitorina ẹ máṣe gbèro ti ọla; ọla ni yio gbèro ohun ara rẹ̀. Buburu inu rẹ̀ to fu ọjọ.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸRIN-DI-LOGUN LẸHIN METALỌKAN.

Adura.

OLUWA, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, jẹ ki iyọnu rẹ titi ki o ma wẹ̀ Ijọ awọn enia rẹ mọ́, ki o sì ma dãbobo o; ati pe, nitori ti kò le duro pẹ̀ li alafia li aìsi iranlọwọ rẹ, ma pa a mọ́ siwaju nipa iranlọwọ ati ore rẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Efes. 3. 13.

MO bẹ̀ nyin ki ãrẹ̀ ki o máṣe mu nyin nitori gbogbo wahalà mi nitori nyin, ti iṣe ogo nyin. Nitori idi eyi ni mo ṣe nfi ẽkun mi kunlẹ̀ lọdọ Babba Jesu Kristi Oluwa wa, lọdọ ẹniti a npè gbogbo idile ti mbẹ li ọrun ati li aiye li orukọ, ki on ki o le fifu nyin, gẹgẹ bi ọpọlọpọ ọrọ̀ ti ogo rẹ̀, lati fi ipá mu nyin lara le nipa Ẹmmí rẹ̀ ni ti ọkọnri

Digitized by Google

inu; ki Kristi ki o le ma gbé ọkkàn nyin nipa igbagbọ́; pe bi a ti fi ẹsẹ nyin mulẹ, ti a sì fi idi nyin kalẹ ninu ifẹ́, ki ẹnyin ki o le mọ́ pẹlu gbogbo awọn enia mimọ́, ohun ti ibú, ati gigun, ati jijìn, ati giga na jasi; ati lati mọ́ ifẹ́ Kristi ti o pọ̀ju ìmọ gbogbo lọ, ki ẹnyin ki o le kún fu gbogbo ẹkún Ọlọrun. Njẹ nisisiyi fu ẹniti o le ṣe lọpọlọpọ jù gbogbo eyiti a mbère, tabi ti a nrò lọ, gẹgẹ bi agbara ti nṣiṣẹ ninu wa, on ni ki a ma fi ogo fu ninu ijọ awọn enia Ọlọrun nipa Kristi Jesu lati irandiran gbogbo, aiye alnipẹkun. Amin.

Ihin-rere. Luku 7. 11.

OSÌ ṣe ni ijọ ekeji, o rè ilu nla kan ti a npè ni Nain; awọn pipọ ninu awọn ọmmọ ẹhin rẹ sì mba a lọ, ati ọ̀pọ enia. Bi o sì ti de ẹnu ọ̀na ti ilu nla na, sì kiyesi i, nwọn ngbé okú ọkọnri kan jade, ọmmọkọnri kan na ṣoṣo ti iya rẹ̀, on sì ṣe opó: ọ̀pọ awọn enia ti ilu na sì wà pẹlu rẹ̀. Nigbati Oluwa sì ri i, ãnu ṣe e fu u, o sì wi fu u pe, Má sọkun mọ́. Nigbati o sì wá, o sì fi ọwọ́ tọ́ aga posi na: awọn ti sì nrù u duro jẹ. O sì wipe, Ọmmọkọnri, mo wi fu ọ, Dide. Okú ọkọnri na sì dide joko, o bẹ̀rẹ si ohùn ifọ̀. O sì fà a le iya rẹ̀ lọwọ́. Ẹ̀ru sì ba gbogbo wọn: nwọn sì nyìn Ọlọrun logo, wipe, Woli nla dide soke ninu wa; ati pe, Ọlọrun sì wa ibẹ̀ awọn enia rẹ̀ wò. Okikí rẹ̀ sì kàn ni gbogbo Judea, ati gbogbo àgbegbe ti o yiká.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸTA-DI-LOGUN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki ore-ọfẹ rẹ ki o ma ṣaju, ati ki o sì ma tọ wa lẹhin nigba-gbogbo, ki o sì mu wa lati fi ara wa fu iṣẹ rere gbogbo titi; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Epistéli. Efes. 4. 1.

NITORINA emi ondè nipa ti Oluwa, mbẹ nyin pe, ki ẹnyin ki o ma rìn bi o ti yẹ fu ìpe na nipasẹ eyiti a pè nyin, pẹlu irẹlẹ ọkkàn gbogbo ati inu tutù, pẹlu ipamọra, ki ẹnyin ki o sì ma fi sũru gbà ọmmọnikeji nyin nipa ifẹ; ki ẹnyin ki o sì ma rọju lati pa iṣọkan ti Ẹmmí mọ ni ìdipọ alafia. Nitori ara kan ni mbẹ, ati Ẹmmí kan, gẹgẹ bi a ti pè nyin niti iretí kan ti a pè nyin si; Oluwa kan, igbagbọ́ kan, baptismu kan, Ọlọrun kan ati Babba gbogbo, ẹniti o wà lori gbogbo, ati nipa gbogbo, ati ninu nyin gbogbo.

Ihin-rere. Luku 14. 1.

O SÌ ṣe, bi o ti wọ ile ọkan ninu awọn olori Farisi lọ lati jẹun li ọjọ isimi. nwọn nṣọ ọ. Sì kiyesi i, ọkọnri kan mbẹ niwaju rẹ ti o li asọnkọn. Jesu sì dahùn o wi fu awọn amofin ati awọn Farisi pe, O tọ́ lati mu-ni lara da li ọjọ isimi? Nwọn sì dakẹ. O sì mu u, o mu u lara da, o sì jọwọ rẹ lọwọ́ lọ; O sì dahùn o wi fu wọn pe, Tani ninu nyin ti yio ni kẹtẹkẹtẹ tabi malu kan, ti o bọ sinu ihò, ti kì yio sì fà a soke lojukan na li ọjọ isimi? Nwọn kò sì le da a li ohùn

Digitized by Google

mọ́ si nkan wọnyi. O sì pa owe kan fu awọn ti a pè jẹun, nigbati o wò bi nwọn ti nyàn ipò ọllá; o sì wi fu wọn pe, Nigbati a ba ti ọdọ ẹnikan pè ọ wá si ibi iyawo, máṣe joko ni ipò ọllá; nitori bi a o ba pè ẹniti o li ọllá jù iwọ lọ. Nigbati ẹniti o pè ọ ati on ba de, a sì wi fu ọ pe, Fu ọkọnri yi li àye; iwọ a sì ma fi itiju mu ipò ẹhin. Ṣugbọn nigbati a ba pè ọ, lọ o sì joko ni ipò ẹhin; nigbati ẹniti o pè ọ ba de, ki o le wi fu ọ pe, Ọrẹ́, bọ soke: nigbana ni iwọ o ni iyìn li oju awọn ti o ba ọ joko ti onjẹ. Nitori ẹnikẹni ti o ba gbé ara rẹ̀ ga, a o rẹ̀ ẹ silẹ; ẹnikẹni ti o ba sì rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ, a o sì gbé e ga.

ỌJỌ ỌLỌRUN EKEJI-DI-LOGUN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ̀, fi ore-ọfẹ́ fu awọn enia rẹ̀, lati duro tìya si idanwò ti aiye, ti ara, ati ti èṣu, ati pẹlu àiya ati inu funfun lati ma tọ̀ ọ lẹhin, iwọ Ọlọrun kanṣoṣo; nipasẹ̀ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 1 Kor. 1. 4.

MO dupẹ̀ fu Ọlọrun mi nigba-gbogbo nitori nyin, nitori ore-ọfẹ́ Ọlọrun ti a fifu nyin nipa Jesu Kristi; nitoripe nipasẹ̀ rẹ̀ li a ti sọ nyin di ọlọrọ̀ li ohun gbogbo, ninu ẹkọ́ gbogbo, ati ninu ìmọ gbogbo; ani gẹ̀gẹ̀ bi a ti fi idi ẹrí Kristi kalẹ̀ ninu nyin: gẹ̀gẹ̀ bi ẹnyin kò ti rẹ̀hin ninu ẹ̀bunkẹbun; ti ẹnyin sì nretí ifarahàn Jesu Kristi Oluwa wa: ẹniti yio sì fi idi nyin kalẹ̀ titi de opin pẹlu, ki ẹnyin ki o le jẹ̀ alailẹgàn li ọjọ Jesu Kristi Oluwa wa.

Digitized by Google

Ihin-rere. Mat. 22. 34.

NIGBATI awọn Farisi gbọ́ pe, o pa awọn Sadusi li ẹnu mọ́, nwọn pe ara wọn jọ. Nigbana li ọkan ninu wọn, ti ṣe amofin, ndan, a wò, o sì bi i lẽre ọ̀rọ̀ kan, wipe, Olukọni, ewo li aṣẹ nla ninu ofin? Jesu sì wi fu u pe, Ki iwọ ki o fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo okkàn rẹ, ati gbogbo inu rẹ, fẹ Ọlọrun Oluwa rẹ. Eyi li ekini ati ofin nla. Ekeji sì dabi rẹ̀, Iwọ fẹ ọmmọ ẹnikeji rẹ bi ara rẹ. Ninu awọn ofin mejeji yi ni gbogbo ofin ati woli rọ̀ mọ́. Bi awọn Farisi ti kó ara wọn jọ, Jẹsu bi wọn, wipe, Kili ẹnyin nrò ti Kristi si? ọmmọ ti tani o ṣe? Nwọn wi fu u pe, Ọmmọ Dafidi ni. O wi fu wọn pe, Ẽha ti ṣe ti Dafidi nipa ẹmmí fi npè e li Oluwa, wipe, OLUWA wi fu Oluwa mi pe, Iwọ joko li ọwọ́ ọtún mi, titi emi yio fi sọ awọn ọtá rẹ di apoti itisẹ rẹ? Njẹ bi Dafidi ba npè e li Oluwa, ẽha ti ri ti o fi ṣe ọmmọ rẹ̀? Kò sì si ẹnikan ti o le da a li ohùn ọ̀rọ̀ kan, bẽni kò si ẹniti o jẹ bi i lẽre ohun kan mọ́ lati ọjọ na lọ.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKỌKAN-DI-LOGUN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLỌRUN, niwọnbi o ti ṣepe lẹhin rẹ awa kò le ṣe ohun ti o wù ọ; Fi ãnu fifuni, ki Ẹmmí Mimọ́ rẹ ki o le ma tọ́ wa, ki o sì ma ṣe akoso àiya wa ninu ohun gbogbo; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. Efes. 4. 17.

EYI ni mọ wi, ti mo sì njẹri niti Oluwa pe, lati isisiyi lọ ki ẹnyin ki o máṣe rìn bi awọn Keferi omiran ti nrìn, ninu ìro asan inu wọn, oyé awọn ẹniti o ṣe òkunkun, ti a sì ti sọdi àjeji si ìwa bi Ọlọrun nipa àimọ ti mbẹ ninu wọn, nitori lile àiya wọn: awọn ẹniti àiya wọn ti le rekọja, ti nwọn sì ti fi ara wọn fu wọ̀bia, lati ma fi ojukòkoro ṣiṣẹ ìwa ẽri gbogbo. Ṣugbọn a kò fi Kristi kọ́ nyin bẹ̃ ri; bi ẹnyin ba ti gbohùn rẹ̀ nitõtọ, ti a ba sì ti kọ́ nyin lati ọdọ rẹ̀ wá, gẹgẹ bi otitọ ti jasi ni ti Jesu: pe ki ẹnyin ki o bọ ara ìwa atijọ silẹ li apakan nipa ogbologbo ọkọnri ni, eyiti o dibajẹ gẹgẹ bi ifẹkufẹ nipa ẹ̀tan; ki ẹnyin ki o sì di titun ni inu nyin nipa ti ẹmmí; ki ẹnyin ki o sì gbé ọkọnri titun ni wọ̀, ẹniti a da li ododo nipa ti Ọlọrun ati li otitọ ìwa mimọ́. Nitorina ẹ fi eke ṣiṣe silẹ, ki olukuluku nyin ki o ma ṣo otitọ fu ọmmonikeji rẹ̀: nitori ẹ̀ya ara ọmmọnikeji wa li awa ṣe. Bi ẹnyin ba binu, ki ẹ má sì ṣẹ̀: ẹ máṣe jẹ ki õrùn wọ̀ sori ibinu nyin: ki ẹ má sì ṣe fi àye fu èṣu. Ki ẹniti o ti njale ri ki o máṣe jale mọ́: ṣugbọn ki o kuku ma ṣe lãlã, ki o ma fi ọwọ́ rẹ̀ ṣiṣẹ ohun ti o dara, ki on ki o le ni lati pín fu ẹniti o ṣe alaìni. Ẹ máṣe jẹ ki ọ̀rọ idibajẹ ti ẹnu nyin jade mọ́, ṣugbọn eyiti o dara lati ma lò fu ẹkọ́ ti o li ère, ki o le ma ṣiṣẹ ore-ọfẹ fu awọn ti o gbọ́. Ẹ má sì ṣe mu Ẹmmí Mimọ́ Ọlọrun binu, ẹniti a ti fi ṣe èdidi nyin si ọjọ idande ni. Ẹ jẹ ki gbogbo ìwa kikorò, ati ibinu, ati irunu, ati ariwọ, ati isọ̀rọ buburu ki a mu u kuro lọdọ nyin, pẹlu gbogbo arankàn: ki ẹnyin ki o sì ma ṣore fu ọmmọnikeji nyin, ẹ ni iyọnu, ki ẹ ma darijì

Digitized by Google

ọmmọnikeji nyin, gẹgẹ bi Ọlọrun nitori Kristi ti darijì nyin.

Ihin-rere. Mat. 9. 1.

JESU bọ sinu ọkọ, o rekọja, o sì wá si ilu on tikararẹ̀. Sì kiyesi i, nwọn gbé ọkọnri kan ti o li ègba wá sọdọ rè, o dubulẹ, lari akete; nigbati Jesu ri igbagbọ́ wọn, o wi fu ẹlẹgba pe, Ọmmọkọnri, tújuka, a dari èṣẹ rẹ jì ọ. Sì kiyesi i, awọn ọkan ninu awọn akọwe nwi ninu ara wọn pe, Ọkọnri yi nsọ òrọ buburu. Jesu sì mọ̀ ìro inu wọn, o wipe, Nitori kili ẹnyin ṣe nrò buburu ninu nyin? Yala ewo li o yajù lati wi, A dari èṣẹ rẹ jì ọ; tabi lati wi, Dide, ki o sì ma rìn? Ṣugbọn ki ẹnyin ki o le mọ̀ pe, Ọmmọ ọkọnri li agbara li aiye lati dari èṣẹ jìni, (o sì wi fu alarun ègba na pe,) Dide, gbé akete rẹ, ki o sì ma lọ si ile rẹ. O sì dide, o lọ si ile rẹ̀. Nigbati ijọ awọn enia sì ri i, ẹnu yà wọn, nwọn yìn Ọlọrun logo, ti o fi irú agbara bayi fu awọn enia.

ỌJỌ ỌLỌRUN OGUN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLODUMARE ati Ọlọrun alãnu julọ, niti inu òpọlọpọ ore rẹ, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, pa wa mọ́ kuro ninu ohun gbogbo ti o le panilara; niti awa mura tan ati li ara, ati li ọkkàn, ki awa ki o le ma fi inu-didùn ṣe ohun wọn-ni ti iwọ fẹ lati ṣe; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Efes. 5. 15.

EKIYESI lati ma rìn ni ìwa pipé, kì iṣe bi awọn alaimoye, ṣugbọn bi awọn

Digitized by Google

ọlọ́gbọn, ẹ ma ṣe irapada igba, nitori buru li awọn ọjọ. Nitorina ki ẹ máṣe alaìmoye, ṣugbọn ẹ ma moye ohun ti ifẹ Oluwa jasi. Ki ẹnyin ki o má sì ṣe kún fu ọti wain, ninu eyiti aṣeju wà; ṣugbọn ẹ kún fu Ẹmmí; ki ẹ sì ma ba ara nyin sọ̀rọ ninu awọn orin mimọ́ (Psalmu), ati orin iyìn, ati orin nipa ti ẹmmí, ẹ ma kọnrin, ki ẹ sì ma fi ọgbọ́n kọnrin li àiya nyin si Oluwa; ẹ ma dupẹ nigba-gbogbo nitori ohun gbogbo fu Ọlọrun ati Babba li orukọ Jesu Kristi Oluwa wa; ẹ ma foribalẹ fu ara nyin ni ìbẹru Ọlọrun.

Ihin-rere. Mat. 22. 1.

JESU wipe, Ijọbba ọrun dabi ọbba kan, ti o ṣe igbeyawo fu ọmmọkọnri rẹ̀, ẹniti o sì rán awọn iranṣẹ rẹ̀ lọ lati pè awọn ti a ti pè tẹlẹ si ibi iyawo: ṣugbọn nwọn kò fẹ wá. O sì tún rán awọn iranṣẹ omiran, wipe, Ẹ wi fu awọn ti a pè pe, Wò o, mo se onjẹ mi tan: a pa malu ati gbogbo ẹran abọpa mi, a sì ṣe ohun gbogbo tan: ẹ wá si ibi iyawo. Ṣugbọn nwọn kò fi-pè nkan, nwọn ba ti wọn lọ, ọkan si ọ̀na oko rẹ̀, omiran si ọ̀na iṣowo rẹ̀: awọn iyokun sì mu awọn iranṣẹ rẹ̀, nwọn ṣe àbukun si wọn, nwọn sì lù wọn pa. Nigbati ọbba sì gbọ́ eyi, o binu: o sì rán awọn ogun rẹ̀ lọ, o pa awọn apania wọn-ni run, o sì kun ilu-nla wọn. Nigbana li o wi fu awọn iranṣẹ rẹ̀ pe, A ṣe ase iyawo tan, ṣugbọn awọn ti a ti pè kò yẹ. Nitorina ẹ lọ si ọ̀na opópo, iyekiye ẹniti ẹ ba ri, ẹ pè wọn wá si ibi iyawo. Bẹ̀li awọn iranṣẹ wọn-ni sì jade lọ si ọ̀na opópo, nwọn sì kó gbogbo awọn ẹniti nwọn ri jọ, ati buburu ati rere: ibi ase iyawo sì kún fu awọn alapejẹ. Nigbati ọbba na wá wò awọn ala-

Digitized by Google

peję, o ri ǫkǫnri kan nibę̀ ti kò ni aṣǫ iyawo: O sì bi i pe, Ǫrę́, iwǫ ti ṣe wǫ̀ ihin wá laìni aṣǫ iyawo? Kò sì le fǫhùn. Nigbana li ǫbba wi fu awǫn iranṣę rę̀ pe, Ẹ dì i tǫwǫ́ tęsę, ę gbé e kuro, ki ę sì sǫ ǫ sinu òkunkun biri-biri; nibę̀ li ękún on ipahin keke yio gbé wà. Nitoriti ǫ̀pǫlǫpǫ li a pè, ṣugbǫn diẹ li a o ri yàn.

ǪJǪ ǪLǪRUN ẸKǪKAN-LE-LOGUN LẸHIN MẸTALǪKAN.

Adura.

OLUWA alãnu, awa mbę̀bę lǫdǫ rę, fifu awǫn enia rę olõtǫ ni idariji ati alafia, ki a le wę̀ wǫn nù kuro ninu ę̀ṣę wǫn gbogbo, ki nwǫn ki o sì ma fi ǫkkàn idakęję sìn ǫ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Efes. 6. 10.

ẸNYIN arakǫnri mi, ę ję alagbara niti Oluwa, ati niti ipá agbara rę̀. Ẹ mu gbogbo ihamǫra Ǫlǫrun wǫ̀, ki ęnyin ki o le duro dè arekereke èṣu. Nitoripe kì iṣe ę̀ję ati ęran ara li awa mba jijakadi, ṣugbǫn awǫn ijoye, awǫn alagbara, awǫn olori ti ibi òkunkun aiye yi, ati awǫn ęmmí buburu ni ibi oju ǫrun. Nitorina ę mu gbogbo ihamǫra Ǫlǫrun wǫ̀, ki ęnyin ki o le kǫjujasi ǫjǫ buburu, lati duro, nigbati ęnyin ba ti ṣe gbogbo wǫn tan. Ẹ duro nitorina, bi awǫn ti a ti fi àmure otitǫ di lęgbę, ki ę sì di awo-àiya ododo ni mǫra; ki a sì fi imura ti Ihin rere alafia wǫ̀ ęsę nyin ni bàta; li akotan, ę mu apatta igbagbǫ́, nipasę eyiti ęnyin o fi le ma paná gbogbo ǫfà iná ti ęni buburu ni. Ki ę sì mu aṣibori irin

Digitized by Google

ti igbala, ati idà ti Ẹmmí ni, ti iṣe ọrọ Ọlọrun: ẹ ma fi igba gbogbo gbadura ni gbogbo adura ati èbẹ nipa ti Ẹmmí, ki ẹ sì ma ṣọra sibẹ pẹlu iduro ṣinṣin gbogbo, ati èbẹ fu gbogbo awọn enia mimọ; ati fu mi, ki a le fi ohùn fu mi, ki emi ki o le ma fi igboiya yà ẹnu mi, lati ma fi ọro ijinlẹ ti Ihin rere hàn, nitori eyiti emi iṣe iranṣẹ ninu èwọn: ki emi ki o le ma fi igboiya sọrọ ninu rẹ, gẹgẹ bi o ti tọ fu mi lati ma sọ.

Ihin-rere. Joh. 4. 46.

OMMỌ alade kan sì wà, ẹniti ara ọmmọkọnri rẹ kò da ni Kapernaumu. Nigbati o sì gbọ pe, Jesu ti Judea jade wá si Galili, o tọ ọ wá, o sì mbẹ ẹ, ki o le sọkalẹ wá lati mu ọmmọkọnri rẹ lara da: nitoriti o wà li oju ikú. Nigbana ni Jesu wi fu u pe, Bikoṣepe ẹnyin ba ri àmi ati iṣẹ iyanu, ẹnyin kì yio gbagbọ. Ọmmọ alade na wi fu u pe, Oluwa, sọkalẹ wá, ki ọmmọ mi ki o to kú. Jesu wi fu u pe, Ma ba ọna rẹ lọ; ọmmọkọnri rẹ yè. Ọkọnri na sì gbà ọrọ ti Jesu sọ fu u gbọ, o sì dide lọ. Bi o sì ti nsọkalẹ lọ, awọn iranṣẹ rẹ pade rẹ, nwọn sì wi fu u pe, Ọmmọkọnri rẹ yè. Nigbana li o bère wakati ti o bẹrẹ si isan lọwọ wọn. Nwọn sì wi fu u pe, Lana ni wakati ekeje ọjọ ni ibà na fi i silẹ. Bẽni babba na sì mọ pe, wakati kan na gan ni, ninu eyi ti Jesu wi fu u pe, Ọmmọkọnri rẹ yè: on tikararẹ sì gbagbọ, ati gbogbo ile rẹ. Eyi sì ni iṣẹ iyanu ekeji, ti Jesu tún ṣe nigbati o ti Judea jade wá si Galili.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN EKEJI-LE-LOGUN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, pa agbo ile rẹ Ijọ awọn enia rẹ mọ titi ninu ìwa-bi-Ọlọrun; pe nipasẹ àbo rẹ ki o le bọ kuro ninu ipọnju gbogbo, ki o sì ma fi ifọkansìn gbé ara le lati ma sìn ọ ninu iṣẹ rere, si ogo Orukọ rẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Fil. 1. 3.

MO dupẹ fu Ọlọrun mi ninu gbogbo ṣiṣe iranti mi fu nyin, emi nfi ayọ bẹbẹ nigba-gbogbo ninu gbogbo adura mi fu gbogbo nyin, nitori ìdapọ nyin ninu Ihin rere lati ọjọ ekini wá titi fi di isisiyi; oju mi sá ti da si ohun kan na yi, pe ẹniti o ti bẹrẹ iṣẹ rere ninu nyin yio sì pari rẹ titi fi di ọjọ Jesu Kristi: gẹgẹ bi o ti tọ fu mi lati rò eyi fu gbogbo nyin, nitori ti ẹnyin ni mi li àiya nyin; niwọn bi o ti ṣepe nipa ìde mi, ati nipa àbo mi ati ifẹsẹ-mulẹ ti Ihin rere, gbogbo nyin ni iṣe alabapin ninu ore-ọfẹ pẹlu mi. Nitoripe Ọlọrun li ẹlẽri mi, bi mo ti nṣafẹri nyin to gidigidi ninu iyọnu Jesu Kristi. Emi sì ngbadura nitori eyi pe, ki ifẹ nyin ki o le ma pọ si i lọpọlọpọ ninu ìmọ ati ninu ọgbọ́n gbogbo; ki ẹnyin ki o le dan ohun ti o yàtọ wò; ki ẹnyin ki o le jasi pipé ati alailẹṣẹ titi fi di ọjọ Jesu Kristi; ki ẹnyin ki o le kún fu eso ododo, ti iṣe nipa ti Jesu Kristi, fu ogo ati iyìn Ọlọrun.

Ihin-rere. Mat. 18. 21.

PETERU wi fu Jesu pe, Oluwa, nigba melo li arakọnri mi yio ṣẹ si mi, ti emi o sì fijì i?

Digitized by Google

titi di igba meje? Jesu wi fu u pe, Emi kò wi fu ọ pe, titi di igba meje, ṣugbọn bikoṣe titi di igba ãdọrin meje. Nitorina ni ijọbba ọrun fi dabi ọbba kan ti nfẹ gbà ìro lọwọ awọn ọmmọ ọdọ rẹ̀. Nigbati o bẹ̀rẹ si iṣiro, a mu ọkan tọ ọ wá, ti o jẹ ẹ li ẹgbarun talenti. Njẹ bi kò ti ni nkan ti yio ṣan, oluwa rẹ̀ fi aṣẹ fu wọn pe ki a tà a, ati obiri rẹ̀, ati awọn ọmmọ rẹ̀, ati ohun gbogbo ti o ni, ki gbese ki o le san. Nitorina li ọmmọ ọdọ na wolẹ lẹba ẹsẹ rẹ̀, o bẹ̀ ẹ, wipe, Oluwa, mu sũru fu mi, emi o san gbogbo rẹ̀ fu o. Nigbana li oluwa ṣãnu fu ọmmọ ọdọ na, o tú u silẹ, o fi gbese na jì i. Ṣugbọn nigbati ọmmọ ọdọ na jade lọ, o sì ri ọkan ninu awọn ọmmọ ọdọ ẹgbẹ rẹ̀, ti o jẹ ẹ li ọgọrun owo idẹ: o gbé ọwọ le e, o fọn ọ li ọrùn, o wipe, San gbese ti iwọ jẹ fu mi. Ọmmọ ọdọ ẹgbẹ rẹ̀ kunlẹ lẹba ẹsẹ rẹ̀, o bẹ̀ ẹ, wipe, Mu sũru fu mi, emi o san gbogbo rẹ̀ fu ọ. On kò sì fẹ; o lọ o gbé e ṣọ sinu tubu titi yio fi san gbese na. Nigbati awọn iranṣẹ ẹgbẹ rẹ̀ ri eyi ti a ṣe, ãnu ṣe wọn gidigidi, nwọn lọ, nwọn sì ṣọ gbogbo ohun ti a ṣe fu oluwa wọn. Nigbati oluwa rẹ̀ pè e tan, o wi fu u pe, Ã iwọ iranṣẹ buburu yi, Mo fi gbogbo gbese ni jì ọ, nitoriti iwọ bẹ̀ mi: iwọ kì sì ṣãnu iranṣẹ ẹgbẹ rẹ, gẹgẹ bi mo ti ṣãnu fu ọ? Oluwa rẹ̀ sì binu, o fi i fu awọn onitubu titi yio fi san gbogbo gbese eyi ti o jẹ ẹ. Bẽ na gẹgẹ ni Babba mi ti mbẹ li ọrun yio sì ṣe fu nyin, bi olukuluku kò ba fi tọkkàn-tọkkàn rẹ̀ dari èṣẹ arakọnri rẹ̀ jì wọn.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸTA-LE-LOGUN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLỌRUN, àbo ati agbara wa, iwọ ti ṣe oloriṣon ti ìwa-bi-Ọlọrun gbogbo; Awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, mura ati gbọ́ adura itọkkànwa ti Ijọ awọn enia rẹ; ki o sì fifuni, ki ohun wọn-ni ti awa nfi igbagbọ́ bère, ki a le ma ri gbà li aba li aṣẹ, nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Fil. 3. 17.

ARAKỌNRI, ẹ ma ṣe ọmmọ lẹhin mi, ki ẹ sì ma kiyesi awọn ti nrìn bẹ̃, gẹgẹ bi awa ti jasi apẹrẹ fu nyin. (Nitori ọpọlọpọ ni nrìn, nipasẹ awọn ẹniti mo ti nwi fu nyin nigbakugba, ani, ti mo sì nsọkun bi mo ti nwi fu nyin nisisiyi, pe ọtá ti agbelebu Kristi ni nwọn: igbẹhin ẹniti iṣe iparun, ikùn ẹniti iṣe ọlọrun wọn, ati ogo ẹniti o wà ninu itiju wọn, awọn ẹniti ´ntọju ohun aiye.) Nitori ọlọ̀tọ ẹgbẹ wa mbẹ li ọrun; nibiti awa pẹlu gbé nwò ọna fu Olugbala, Jesu Kristi Oluwa ni: ẹniti yio pa ara ọ̀si wa dà, ki o le ri gẹgẹ bi ara on tikararẹ̀, ti o li ogo, gẹgẹ bi iṣẹ agbara nipasẹ eyiti on le fi ṣẹgun ohun gbogbo fu ara rẹ̀.

Ihin-rere. Mat. 22. 15.

NIGBANA li awọn Farisi lọ, nwọn ngbìmọ bi nwọn yio ti ṣe di i mu li ọ̀rọ rẹ̀. Nwọn sì rán awọn ọmmọ ẹhin wọn pẹlu awọn ọmmọ ẹhin Herodu lọ sọdọ rẹ̀, wipe, Olukọni, awa mọ̀ pe olotitọ ni iwọ, iwọ sì nkọni li ọna Ọlọrun li otitọ, bẹ̃ni iwọ kò woju ẹnikẹni: nitoriti iwọ kò ṣe isaju fu enia kan. Njẹ wi

Digitized by Google

fu wa, Iwọ ti rò ọ si? O tọ́ lati ma san owode fu Kesari, tabi kò tọ́? Ṣugbọn Jesu mọ̀ ìro buburu wọn, o sì wi fu wọn pe Ẽsẹ ti ẹnyin fi ndan mi wò, ẹnyin agabagebe? Ẹ fi owode kan hàn mi. Nwọn sì mu owo idẹ kan tọ̀ ọ wá. O sì bi wọn pe, Aworan ati akọle tali eyi? Nwọn wi fu u pe, Ti Kesari ni. Nigbana li o wi fu wọn pe, Njẹ ẹ fi ohun ti ṣe ti Kesari fu Kesari; ati ohun ti ṣe ti Ọlọrun fu Ọlọrun. Nigbati nwọn sì ti gbọ́ ọ̀rọ wọnyi, ẹnu yà wọn, nwọn fi i silẹ, nwọn sì ba ti wọn lọ.

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKẸRIN-LE-LOGUN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, tú awọn enia rẹ silẹ kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn; pe nipasẹ ọ̀pọlọpọ ore rẹ ki a le yọ gbogbo wa kuro ninu ìde ẹ̀ṣẹ nwọn-ni, nipa allera wa ti awa ti da: Fi eyi funi, Babba ọrun, nitori Jesu Kristi, Olubukun ati Olugbala wa. *Amin.*

Episteli. Kol. 1. 3.

AWA ndupẹ fu Ọlọrun ati Babba Jesu Kristi Oluwa wa, awa sì ngbadura fu nyin nigba-gbogbo, nigbati awa gburó igbagbọ́ nyin niti Kristi Jesu, ati ifẹ́ ti ẹnyin ni si gbogbo awọn enia mimọ́. Nitori iretí ti a gbé leke fu nyin li ọrun, nipa eyiti ẹnyin ti gbọ́ ṣaju ninu ọ̀rọ otitọ nipa Ihin rere; eyiti o tọ̀ nyin wá, bi o sì ti ri ni gbogbo aiye; ti o sì nso eso jade, bi o sì ti nṣe ninu nyin pẹlu, lati ọjọ ti ẹnyin ti gbọ́ ọ, ti ẹnyin sì ti mọ̀ ore-ọfẹ Ọlọrun li otitọ: gẹgẹ bi ẹnyin sì

Digitized by Google

ti kọ́ lati ọwọ́ Epafra iranṣẹ ẹgbẹ wa olufẹ, ẹniti iṣe olododo alufa Kristi fu nyin; ẹniti o sì ti ròhin ifẹ́ nyin niti Ẹmmí fu wa pẹlu. Awa pẹlu nitori idi eyi na, lati ijọ ti a ti gburó rẹ̀, awa kò sì simi lati ma gbadura fu nyin, ati lati ma bẹ̀bẹ pe ki ẹnyin ki o le kún fu ìmọ ifẹ́ rẹ̀ ninu ọgbọ́n ati imoye gbogbo ti iṣe ti Ẹmmí; ki ẹnyin ki o le ma rìn ni yiyẹ niti Oluwa si ìwu gbogbo, ki ẹnyin ki o le jẹ eleso ninu iṣẹ rere gbogbo, ki ẹ sì le ma di pipọ ninu ìmọ Ọlọrun; ki a le fi ipá gbogbo mu nyin li ọkkàn le, gẹgẹ bi agbara rẹ̀ ti o li ogo, sinu sũru ati ipamọra gbogbo pẹlu ayọ̀; awa ndupẹ fu Babba, ẹniti o ti mu wa di alabapin ninu ilẹnini ti awọn enia mimọ́ ninu imọlẹ.

Ihin-rere. Mat. 9. 18.

BI Jesu ti nsọ nkan wọnyi fu wọn, kiyesi i, ijoye kan tọ̀ ọ wá, o sì tẹriba fu u, wipe, Ọmmọbiri mi kú nisisiyi, ṣugbọn wá fi ọwọ́ rẹ̀ le e, on yio sì yè. Jesu dide, o sì ba a lọ, ati awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀. Sì kiyesi i, obiri kan ti o nrun ọ̀rin èjẹ li ọdún mejila, o wá lẹhin rẹ̀, o fi ọwọ́ kàn iṣẹtí aṣọ rẹ̀. O wi ninu ara rẹ̀ pe, Bi mo ba sá le fi ọwọ́ kàn aṣọ rẹ̀, ara mi yio da. Nigbati Jesu sì yi ara rẹ̀ pada ti o ri i, o wipe, Ọmmọbiri, túju ka, igbagbọ́ rẹ mu ọ lara da. A sì mu obiri na lara da ni wakati kan na. Nigbati Jesu sì de ile ijoye na, o ba awọn afọnfere ati awọn enia npa ariwo, O wi fu wọn pe, Bìla; nitori ọmmọbiri na kò kú, sisùn li o sùn. Nwọn sì fi rin ẹrin ẹlẹyà. Ṣugbọn nigbati a sì ṣe ti awọn enia jade, o bọ sile, o sì fà ọmmọbiri na li ọwọ́ soke; bẽli ọmmọbiri na sì dide. Okikí sì kan ká ilẹ na gbogbo.

Digitized by Google

ỌJỌ ỌLỌRUN ẸKARUN-DI-LỌGBỌN LẸHIN MẸTALỌKAN.

Adura.

OLUWA, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, rú ifẹ awọn enia rẹ olõtọ soke; ki nwọn ki o le ma so eso iṣẹ rere jade li ọpọlọpọ, ki a sì le ma ti ọdọ rẹ san a fu wọn li ọpọlọpọ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Jer. 23. 5.

OLUWA wipe, kiyesi i, ọjọ ni mbọ, ti emi o gbé Ekagiododo dide si Dafidi, Ọbba kan yio sì jẹ yio sì ni asiki, yio sì ma ṣe idajọ ati otitọ lori ilẹ. Li ọjọ ni li a o gbà Juda là Israẹli yio sì ma gbé li alafia: eyi sì li orukọ rẹ ti a o ma fi pè e. OLUWA OLODODO WA. Nitorina kiyesi i, ọjọ ni mbọ li Oluwa wi, ti wọn kì yio ma wi mọ pe, Oluwa mbẹ ti o mu awọn ọmmọ Israẹli jade lati ilẹ Egipti wá; ṣugbọn bikoṣepe, Oluwa mbẹ, ti o mu wa oke, ti o sì ṣe amonà awọn iru ọmmọ ile Israẹli lati ilu ariwa jade wá, ati lati ilu gbogbo jade wá, nibiti mo gbé ti le nwọn si; nwọn o sì ma gbé inu ilẹ ti ara nwọn.

Ihin-rere. Joh. 6. 5.

NIGBATI Jesu sì gbé oju rẹ soke, ti o sì ri ọpọ awọn enia wá sọdọ rẹ, o wi fu Filipu pe, Nibo li a o ti rà akara, ki awọn wọnyi ki o le jẹ? O sì sọ eyi lati dan a wò; nitoriti on tikararẹ mọ ohun ti on o ṣe. Filipu da a lohùn pe, Igba owo idẹ akara kò to fu wọn, ti olukuluku wọn iba fi mu diẹ diẹ. Ọkan ninu awọn ọmmọ ẹhin rẹ, Andru, arakọnri Simon Peteru wi fu u pe, Ọmmọkọnri kan mbẹ nihinyi,

Digitized by Google

ti o ni iṣu akara Krite marun, ati ẹja kekere meji: ṣugbọn kili wọn-ni ninu ọpọ awọn enia wọnyi? Jesu sì wipe, Ẹ mu ki awọn enia na joko. Koriko pipọ sì wà nibẹ. Bẹ̃li awọn ọkọnri na joko, ni kikà nwọn to lwọn ẹgbẹdọgbọn ẹnia. Jesu sì mu iṣu akara wọn-ni; nigbati o sì ti dupẹ, o pín wọn fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀, awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ sì pín wọn fu awọn ti o joko; bẹ̃ gẹgẹ sì li ẹja ni lwọn bi nwọn ti nfẹ. Nigbati nwọn sì yó, o wi fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ pe, Ẹ kó ajẹkù ti o kù jọ, ki ohunkohun máṣe ṣegun. Nitorina nwọn kó wọn jọ pọ̀, a sì kún agbọn mejila li ajẹkù ti iṣu akara Krite marun, li eyi ti o ṣikù, ti o sì pọ̀ju fu awọn ti o jẹ. Nitorina nigbati awọn ọkọnri na ri iṣẹ iyanu ti Jesu ṣe, nwọn wipe, Lõtọ eyi ni woli na ti mbọ̀ wá aiye.

ỌJỌ TI ANDRU APOSTELI MIMỌ́.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o fi irú orẹ-ọfẹ ni fu Andru Aposteli rẹ̀ mimọ́, ti o fi yara gbọ̀ lpe ti Jesu Kristi Ọmmọ rẹ̀, ti o sì tẹ̀le e lai dẹṣẹ duro; Fifu gbogbo wa, bi a ti npè wa nipasẹ Ọrọ mimọ́ rẹ̀, lojukan na ki awa ki o le fi igbọran fi ara wa fu ati mu ofin mimọ́ rẹ̀ ṣẹ̀: nitori Jesu Kristi na Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Rom. 10. 9.

BI iwọ ba fi ẹnu rẹ̀ jẹwọ Jesu Oluwa, ti iwọ sì gbagbọ́, li ọkkàn rẹ̀ pe, Ọlọrun jí i dide kuro ninu okú, a o gbà ọ là. Nitori okkàn li enia fi gbagbọ́ si ododo; ẹnu li a sì fi jẹwọ si igbala. Nitori Iwe mimọ́ Ọlọrun wipe, Ẹni-

Digitized by Google

kẹni ti o ba gbà a gbó kì yio damu. Nitoriti kò si ìyatọ ninu Ju ati Helene: nitori Oluwa kan na li o lọrọ fu gbogbo awọn ti npè orukọ rẹ. Ẹnikẹni ti o ba sá pè orukọ Oluwa a o gbà a là. Nwọn o ha ti ṣe pè orukọ ẹniti nwọn kò gbagbó? nwọn o ha ti ṣe gbà ẹniti nwọn kò gburó rẹ ri gbó? nwọn o ha ti ṣe gbó laìni oniwasu? Nwọn o ha ti ṣe wasu, bikoṣepe a rán wọn? gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Ẹsẹ awọn ti o nṣe wasu Ihin rere alafia ti dara to, ati nwọn ti sì nwasu ihin ayọ ohun rere! Ṣugbọn gbogbo wọn kò gbà Ihin rere gbó. Isaia sá wipe, Oluwa, tali o gbà iwasu wa gbó? Njẹ nipa igbọran ni igbagbó ti wá, ati igbọran nipa ọrọ Ọlọrun. Ṣugbọn mo ni, Awọn kò ha gbó bi? Nitõtọ, ohùn wọn jade lọ si gbogbo ilẹ, ati ọrọ wọn si opinlẹ aiye. Ṣugbọn mo ni, Israeli kò ha mọ bi? Mose tète wipe, Emi o fi awọn ti kì iṣe enia mu nyin jowú, ati awọn alaìmoye enia li emi o fi bi nyin ninu. Ṣugbọn Isaia tilẹ laiya, o sì wipe, A ri mi lọdọ awọn ti kò wá mi kiri; awọn ti kò bère mi li a fi mi hàn fu. Ṣugbọn fu Israeli li o wipe, Li ọjọ gbogbo li emi n-nà ọwọ mi si awọn alaìgbọran ati alariwisi enia.

Ihin-rere. Mat. 4. 18.

JESU nrìn letí adagun Galili, o ri awọn arakọnri meji, Simon, ẹniti a npè ni Peteru, ati Andru arakọnri rẹ, nwọn nsọ àwọn sinu adagun: nitoriti nwọn ṣe apẹja. O sì wi fu wọn pe, Ẹ ma tọ mi lẹhin, emi o sì sọ nyin di apẹja enia. Nwọn sì fi àwọn wọn silẹ lojukan na, nwọn ntọ ọ lẹhin. Bi o sì ti nlọ siwaju ibẹ, o ri awọn arakọnri meji, Jakobu ọmmọ Sebede, ati Johanu arakọnri rẹ, ninu ọkọ pẹlu Sebede babba wọn, nwọn ndi àwọn

Digitized by Google

wọn ; o sì pè wọn. Lojukan na nwọn sì fi ọkọ ati babba wọn silẹ, nwọn ntọ ọ lẹhin lọ.

ỌJỌ TI TOMA APOSTELI MIMỌ.

Adura.

OLODUMARE ati lai Ọlọrun alãye, nitori ifẹsẹ-mulẹ siwaju ti igbagbọ ni, iwọ ti o jẹ ki Toma Aposteli rẹ mimọ ki o ṣe iyemeji niti ajinde Ọmmọ rẹ ; Fifu wa bẹ ni pipé ṣanṣan, ati li alṣiye-meji kan, lati gbagbọ niti Jesu Kristi ọmmọ rẹ, lai ki a má le ri igbagbọ wa bawi niwaju rẹ. Oluwa, gbọ ti wa, nitori Jesu Kristi na, fu ẹni, pẹlu rẹ ati Ẹmmí Mimọ, ti gbogbo ọlá ati ogo wà fu, nisisiyi ati lailai. *Amin.*

Episteli. Efes. 2. 19.

NJẸ nitorina ẹnyin kì iṣe alejò ati atipo mọ, ṣugbọn àjumọ jẹ ọlọtọ pẹlu awọn enia mimọ, ati awọn ara ile Ọlọrun ; a si ngbé nyin ró lori ipilẹ ti awọn Aposteli, ati ti awọn woli, Jesu Kristi tikararẹ ni pàtaki okuta igun ile ; ninu ẹniti a fi tẹyẹtẹyẹ ṣisẹ gbogbo ile na ṣọkan pọ ti ndàgba soke fu tempeli mimọ kan ni ti Oluwa : ninu ẹniti a ngbé nyin ró pẹlu fu ibujoko kan ti Ọlọrun nipa Ẹmmí.

Ihin-rere. Joh. 20. 24.

ṢUGBỌN Toma, ọkan ninu awọn mejejila, ti a npè ni Didimu, kò wà pẹlu wọn nigbati Jesu de. Nitorina awọn ọmmọ ẹhin iyokù wi fu u pe, Awa ti ri Oluwa. Ṣugbọn o wi fu wọn pe, Bikoṣepe emi ba ri apa iṣó li

Digitized by Google

ọwọ́ rẹ̀, ki emi ki o sì fi ika mi bọ apa iṣó wọn-ni, ki emi ki o sì tẹ̀ ọwọ́ mi bọ ìha rẹ̀, emi kì yio gbagbọ́. Lẹhin ijọ́ mẹjọ́ awọn ọmmọ ẹhin sì tun wà ninu ile, ati Toma pẹlu: nigbati gbogbo ilẹkun sì ti sé tan, Jesu de, o sì duro larin wọn, o sì wipe, Alafia fu nyin. Nigbana li o wi fu Toma pe, Mu ika rẹ wá nihin, ki o sì wò ọwọ́ mi; sì mu ọwọ́ rẹ wá nihin, ki o sì tẹ̀ ẹ bọ ìha mi: ki iwọ ki o máṣe alaìgbagbọ́ mọ́, ṣugbọn gbagbọ́. Toma dahùn o sì wi fu u pe, Oluwa mi ati Ọlọrun mi. Jesu wi fu u pe, Toma, nitoriti iwọ ti ri mi ni iwọ fi gbagbọ́: alabukún-fu li awọn ti kò ti iri, ti nwọn sì ti gbagbọ́. Ati ọpọlọpọ iṣẹ̀ àmi omiran ni Jesu ṣe nitõtọ niwaju awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀, ti a kò kọ sinu iwe yi: ṣugbọn iwọnyi li a kọ, ki ẹnyin ki o le gbagbọ́ pe, Jesu ni iṣe Kristi, Ọmmọ Ọlọrun; ati pe gbigbà a gbọ́, ki ẹnyin ki o le ni ìye nipa orukọ rẹ̀.

ỌJỌ TI IYIPADA TI PAULU APOSTELI MIMỌ́.

Adura.

OLỌRUN, nipasẹ̀ iwasu ti Paulu Aposteli mimọ́ ati alabukún-fu, iwọ ti o mu imọlẹ̀ ti Ihin-rere lati tàn jalẹ̀ aiye; Ifunni, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ̀, ki awa, ti o ni iyipada rẹ̀ ti o yanu ni iranti, ki awa ki o le ma fi ọpẹ́ wa hàn jade fu ọ nitori na, nipasẹ̀ ìtọ lẹhin ẹkọ́ mimọ́ ti o kọ́ni; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Epistéli. Iṣe 9. 1.

ATI Saulu, titi o fi di isisiyi, o nmí ìlọ ati pipa si awọn ọmmọ ẹhin ti Oluwa, nigbati

Digitized by Google

o tọ olori awọn alufa lọ, O bẹbẹ iwe lọwọ rẹ si Damasku si sinagogu pe, bi on ba ri ẹnikẹni li ọna yi, iba ṣe ọkọnri, iba ṣe obiri, ki on ki o le mu u ni didè wá si Jerusalemu. Bi o sì ti nlọ, o sì sumọ etí Damasku: imọlẹ sì mọ, yi i ká lojijì lati ọrun wá. Nigbati o sì ṣubu lulẹ, o gbọ ohùn ti o nfọ si i pe, Saulu, Saulu, ẽṣe ti iwọ fi nṣe inunibini si mi? On sì wipe, Iwọ tani, Oluwa? Oluwa sì dahùn pe, Emi Jesu ni, ẹniti iwọ nṣe inunibini si: o ṣoro fu ọ lati tapá si ẹgún. O sì nwa-rìri, ẹnu sì yà a, o ni, Oluwa, kili iwọ nfẹ ki emi ki o ṣe? Oluwa sì wi fu u pe, Dide, ki o sì lọ si ilu nla na, nibẹ li a o sọ fu ọ li ohun ti iwọ o ṣe. Awọn ọkọnri ti sì mba a rìn pọ duro, kẹkẹ pa mọ wọn li ẹnu, nwọn ngbọ ohùn, ṣugbọn nwọn kò ri ẹnikan. Saulu sì dide ni ilẹ; nigbati oju rẹ sì ṣí, kò ri ẹnikẹni: ṣugbọn nwọn fà a li ọwọ, nwọn sì mu u wá si Damasku. O sì gbé ijọ mẹta li aìrina, kò sì jẹ, bẽni kò sì mu. Ọkọnri kan ọmmọ ẹhin sì wà ni Damasku, ti a npè ni Anania; on li Oluwa sì wi fu li ojuran pe, Anania. O sì dahùn wipe, Wò o, emi ni yi, Oluwa. Oluwa sì wi fu u pe, Dide, ki o sì lọ si ọna igboro ti a npè ni Ọganran, ki iwọ ki o sì bère ẹnikan, ti a npè ni Saulu, ara Tarsu, ni ile Juda: sá kiyesi i, o ngbadura. O sì ti ri ọkọnri kan li ojuran ti a npè ni Anania o wọle, o sì fi ọwọ le e, ki o le riran rẹ. Anania sì dahùn wipe, Oluwa, mo ti gburó ọkọnri yi lọdọ ọpọ awọn enia, ni ìwọn buburu ti o ṣe si awọn enia mimọ, rẹ ni Jerusalemu: O sì gbà agbara lati ọdọ awọn olori alufa wá si ihinyi, lati dè gbogbo awọn ti npè orukọ rẹ. Ṣugbọn Oluwa wi fu u pe, Ma ba ti rẹ lọ: nitoriti iṣe ohun ìlo ãyo fu mi, lati mu orukọ mi lọ si iwaju awọn Keferi, ati ti awọn ọba,

Digitized by Google

ati niwaju awọn ọmmọ Israeli: nitori emi o fi hàn a ni ìya ohun pipọ ti yio jẹ nitori orukọ mi. Anania sì mu ọna rẹ̀ pọ̀n, o sì wọ̀ ile na; nigbati o sì fi ọwọ́ rẹ̀ le e, o ni, Saulu Arakọnri, Oluwa li o rán mi, Jesu ti o fi ara hàn fu ọ li ọ̀na bi iwọ ti mbọ̀ wá, ki iwọ ki o le rìran rẹ, ki o sì le kún fu Ẹmmí Mimọ́. Lojukan na ohun kan bọ kuro li oju rẹ̀ bi ipẹpẹ: o sì riran bi a ti nwi yi, nigbati o sì dide, a baptisi rẹ̀. Nigbati o sì jẹun, ara rẹ̀ le. Saulu sì wà pẹlu awọn ọmmọ ẹhin ni Damasku ni ijọ melokan. Lojukan na o sì wasu Kristi ninu sinagogu pe, on li Ọmmọ Ọlọrun. Ṣugbọn ẹnu yà gbogbo awọn ti o ngbọ́, nwọn sì wipe, Ọkọnri yi kì nṣe inunibini si awọn ti npè orukọ yi ni Jerusalemu, ti o sì ti itori na wá si ihinyi, ki o le mu wọn ni didè lọ ifi fu awọn olori alufa? Ṣugbọn agbara Saulu npọ̀ si i, o sì damu awọn Ju ti o wà ni Damasku, o nfi hàn pe, eyiyi na ni Kristi.

Ihin-rere. Mat. 19. 27.

PETERU dahùn, o sì wi fu u pe, Wò o, awa ti fi gbogbo rẹ̀ silẹ, awa sì ntọ̀ ọ lẹhin; njẹ kili awa o ha ni? Jesu sì wi fu wọn pe, Lõtọ ni mo wi fu nyin, Pe ẹnyin ti ẹ ntọ̀ mi lẹhin ni igba atunbi, nigbati Ọmmọ ọkọnri yio joko lori itẹ́ ogo rẹ̀, ẹnyin o sì joko pẹlu lori itẹ́ mejila, ẹnyin o ma ṣe idajọ awọn ẹ̀ya Israeli mejejila. Ati gbogbo ẹniti o fi ile silẹ, tabi arakọnri, tabi arabiri, tabi babba, tabi iya, tabi aya, tabi ọmmọ, tabi ilẹ, nitori orukọ mi, nwọn yio ri ọrọrun gbà, nwọn yio sì jogún ìye alnipẹkun. Ṣugbọn ọ̀pọ̀ awọn ti o ṣiwaju ni yio kẹhin; awọn ti o kẹhin ni yio sì ṣiwaju.

Digitized by Google

ADURA.

IMUWÁ-FIHÀN KRISTI SINU TEMPELI,

Ti a ma pè ni

IWẸNUMỌ TI MARIA WUNDIA MIMỌ́.

Adura.

OLODUMARE ati lai Ọlọrun alãye, awa nfi irẹlẹ ohùn bẹ̀bẹ̀ lọdọ Ọlá-nla rẹ, pe bi a ti mu Ọmmọ bíbi rẹ na kanṣoṣo wá fihàn ninu tempeli li oni, ninu ìwa ẹda ti ara wa, bẹ̃ni ki a sì mu wa wá sọdọ rẹ pẹlu àiya funfun ati mimọ́, nipasẹ Ọmmọ rẹ na Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Mal. 3. 1.

KIYESI i, emi o ran onṣẹ mi, on yio sì tun ọ̀na mi ṣe niwaju mi: ati Oluwa ẹniti ẹnyin nwá, yio sì wá li ojiji sinu tempili rẹ̀, ani o nṣẹ majẹmu ni, ẹniti inu nyin dùn si: Kiyesi i, yio wá, li Oluwa ti awọn ọmmọ ogun wi. Ṣugbọn awọn ta ni yio le igba ọjọ wiwá rẹ̀? ta ni yio sì duro nigbati ọ ba fi ara hàn? nitoriti ọ dabi iná adakoro, ati bi ọṣẹ alagbàfọ: yio sì joko bi adakoro ati bi alawẹnu fadaka; yio sì wẹ̀ awọn ọmmọ Lefi mọ́, yio sì dà wọn bi wura ati fadaka; ki nwọn ki o le ma ru ẹbọ ọrẹ ododo si Oluwa. Nigbana li ẹbọ ọrẹ ti Juda ati ti Jerusalẹmu yio ṣe didùn mọ́ fu Oluwa, bi ọjọ igbani, ati bi ọdún atijọ. Emi yio sì sunmọ́ nyin wa si idajọ; emi o sì ma ṣe ẹlẹri ti ọ yara si awọn oṣo, ati si awọn àgbere, ati si awọn abura ke, ati si awọn ti nrẹ́ awọn alagbaṣọ jẹ ninu owo iṣẹ wọn, opó ati ọmmọ alàìni babba, ati si awọn ti nyi alejò pada kuro ninu ohun titọ́ rẹ̀ ti kò sì bẹru mi, li Oluwa awọn ọmmọ ogun wi.

Digitized by Google

Ihin-rere. Luku 2. 22.

NIGBATI ọjọ iwẹnu rẹ (Maria) sì pé gẹgẹ bi ofin Mose, nwọn gbé e (Jesu) wá si Jerusalemu lati fi i fu Oluwa; (bi a ti kọ ọ sinu ofin ti Oluwa pe, Gbogbo ọmmọ ọkọnri ti o ṣe akọbi, on li a o pè ni mimọ́ fu Oluwa;) ati lati rubọ gẹgẹ bi a ti wi i li ofin ti Oluwa, Àdaba meji tabi ọmmọ ẹiyẹle meji. Sì kiyesi i, ọkọnri kan wà ni Jerusalemu, orukọ rẹ a ma jẹ Simeon; ọkọnri na sì ṣe olõtọ ati olufọkkànsin, o duro dè itunu Israeli: Ẹmmí Mimọ́ sì wà lara rẹ. A sì ti fihàn a lati ọdọ Ẹmmí Mimọ́ na wá pe, on kì yio ri ikú, ki o to ri Kristi ti Oluwa. O sì ti ipa ẹmmí na wá sinu tempeli (ile Ọlọrun:) nigbati awọn õbi rẹ sì gbé ọmmọ na Jesu wá, lati ṣe fu u bi iṣe ofin, nigbana li o sì gbé e li apa rẹ, o fi ibukún fu Ọlọrun, o ni, Oluwa, nigbayi li o to jọwọ ọmmọ ọdọ rẹ lọwọ́ lọ li alafia, gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ: nitoriti oju mi ti ri igbala rẹ na, ti iwọ ti pèse silẹ niwaju awọn enia gbogbo; imọlẹ lati mọ́ si awọn Keferi, ati ogo Israeli awọn enia rẹ. Ẹnu sì yà Josefu ati iya rẹ si nkan ti a nsọ si i wọnyi. Simeon sì sure fu wọn, o sì wi fu Maria iya rẹ pe, Kiyesi i, a gbé ọmmọ yi kalẹ fu iṣubu ati idide ti ọ̀pọ awọn enia ni Israeli; ati fu àmi ti a o sọ̀rọ òdi si; (idà yio sì gún iwọ na li ọkkàn pẹlu,) ki a le fi ironu ti ọ̀pọ ọkkàn hàn. Ẹni kan sì mbẹ, Ana woli, ọmmọbiri Fanueli, li ẹya Aseri: ọjọ ogbó rẹ pọ̀, o ti ba ọkkọ gbé li ọdún meje lati igba wundia rẹ wá; O sì ṣe opó ìwọn ọdún mẹrin le lọgọrin, ẹniti kò kuro ni tempeli (ile Ọlọrun,) o sì nfi àwẹ ati adura sìn Ọlọrun lọsán ati loru. O sì wọ̀le li akokò na, o sì dupẹ fu Oluwa pẹlu, o sì sọ̀rọ rẹ fu gbogbo awọn ti o duro dè idande ni Jerusalemu. Nigbati nwọn sì ti ṣe

Digitized by Google

nkan gbogbo tan gẹgẹ bi ofin ti Oluwa, nwọn pada lọ si Galili, si Nasareti ilu nla wọn. Ọmmọ na sì dàgba, o sì le li ọkkàn, o sì kún fu ọgbọ́n: ore-ọfẹ Ọlọrun sì mbẹ lara rẹ̀.

ỌJỌ TI MATIA APOSTELI MIMỌ́.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, ni ipò Juda ti ṣe onikupani, iwọ ti o yàn Matia olõtọ iranṣẹ rẹ, ki a kà a kún iye awọn Aposteli mejila ni; Fifuni pe, bi a ti npa Ijọ awọn enia rẹ mọ́ nigba-gbogbo kuro ninu awọn eke Aposteli, ki a le ma tọ́ ọ, ki a sì le ma ṣe amọ̀na rẹ̀ nipasẹ awọn olõtọ ati olododo olutọju, nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Iṣe 1. 15.

NI ijọ wọn-ni ni Peteru sì dide duro li awujọ ti awọn ọmmọ ẹhin (iye orukọ ti awọn enia gbogbo ninu ijọ jẹ ọgọfa,) o ni, ẹnyin alàgba ati arakọnri, Iwe mimọ́ Ọlọrun yi kò le ṣe ki o má ti ṣẹ, ti Ẹmmí Mimọ́ ti sọtẹlẹ li ẹnu Dafidi nipa ti Juda, ti o ṣe amọ̀na fu awọn ti o mu Jesu. Nitoriti a kà a sinu wa, o sì ni ipa ninu iṣẹ aposteli yi. Njẹ ọkọnri yi sá sì fi èrè èṣẹ rà ilẹ kan; nigbati o ṣubu li ogedengbe, o bẹ́ li agbedemeji, gbogbo ifọn rẹ̀ sì tú jade. A sì gbọ́ ihin na kalẹ lọdọ gbogbo awọn ara Jerusalemu; nitori rẹ̀ li a fi npè igbẹ́ na ni Akeldama li ède wọn, eyini ni, Igbẹ́ èjẹ. A sá kọ ọ ninu Iwe Psalmu pe, Ki ibujoko rẹ̀ ki o di ahoro, ki ẹni kan ki o máṣe gbé ibẹ̀ mọ́: ati iṣẹ ibojuwò rẹ̀ ni ki ẹlomiran ki o gbà. Njẹ o yẹ, ninu awọn ọkọnri wọnyi ti nwọn ti

Digitized by Google

mba wa rìn nigba-gbogbo ti Jesu Oluwa fi nwǫ̀le, ti o sì njade ninu wa, bẹ̀rẹ̀ si i lati igba baptismu Johanu wá, titi o fi di ọjọ na ti a gbé e lọ soke kuro lọdọ wa, ki awa ki o yàn ọkan ṣe ẹlẹ̀ri ti ajinde rẹ̀ pẹlu wa. Nwọn sì yàn awọn meji, Josefu ti a npè ni Barsaba, ti nwọn sì sọ apele rẹ̀ ni Justu, ati Matia. Nwọn sì gbadura, nwọn sì ni, Iwọ, Oluwa, ti o mọ̀ ọkkàn awọn enia gbogbo, fihàn ninu awọn mejeji yi, ewo ni iwọ yàn, ki o le gbà ipa kan ni iṣẹ́ alufa, ati ni iṣẹ́ aposteli yi, ni ibiti Juda ti fi ẹ̀ṣẹ́ ṣubu, ki o le lọ si ipò ti rẹ̀. Nwọn sì di ìbo wọn; ìbo sì mu Matia; a sì kà a kún awọn aposteli iyokù mọkanla.

Ihin-rere. Mat. 11. 25.

LAKOKÒ na ni Jesu dahùn, o sì wipe, Mo dupẹ lọwọ́ rẹ, Babba, Oluwa ọrun on aiye, nitoriti iwọ pa nkan wọnyi mọ́ kuro li oju awọn ọlọ́gbọn ati amoye, iwọ sì fi wọn hàn fu awọn ọmọmọ ọwọ. Gẹgẹ bẹ̀ẹ̀ na ni, Babba, nitori bẹ̀li o tọ́ li oju rẹ. Ohun gbogbo li a fifu mi lati ọdọ Babba mi wá: kò sì si ẹniti o mọ̀ Ọmmọ, bikoṣe Babba; bẹ̀ni kò sì si ẹniti o mọ̀ Babba bikoṣe Ọmmọ, ati ẹnikẹni ti Ọmmọ fẹ o fi i hàn fu. Ẹ wá sọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nṣiṣẹ́, ti a sì di ẹrù wuwo le lori, emi o sì fi isimi fu nyin. Ẹ gbà àjaga mi si ọrùn nyin, ki ẹ sì ma kọ́ ẹkọ́ ti emi; nitori oninu titẹ̀ ati oninu tutù li emi; ẹnyin o sì ni isimi fu ọkkàn nyin. Nitoriti àjaga mi rọrùn, ẹrù mi si fuyẹ.

Digitized by Google

ỌJỌ TI SISỌFU TI MARIA WUNDIA ALABUKUNFU.

Adura.

OLUWA, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, tú ore-ọfẹ rẹ si wa li àiya; pe bi awa ti mọ imawọ ẹran ara ti Ọmmọ rẹ Jesu Kristi nipa iṣẹriran lati ọwọ angeli kan wá, bẹ gẹgẹ nipa agbelebu ati ijiya rẹ, ki a le mu wa wá sibi ogo ajinde rẹ; nipasẹ Jesu Kristi na Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Isa. 7. 10.

PẸLUPẸLU, Oluwa tun sọ fu Ahas pe, Bère àmi kan lọwọ Oluwa Ọlọrun rẹ; bère rẹ iba iṣe ni ọgbọn tabi ni giga loke. Ṣugbọn Ahas wipe, Emi kì yio bère bẹli emi kì yio dan Oluwa wò. On sì wipe, Ẹ ma gbọ nisisiyi ẹnyin arale Dafidi; Iṣe ohun kekere fu nyin lati da enia li agara? nje ẹnyin o sì da Ọlọrun mi li agara pẹlu? Nitorina Oluwa tikararẹ ni yio fi àmi kan hàn nyin; Kiyesi i, Wundia kan yio li oyun, yio sì bimmọkọnri kan, yio sì ma pe orukọ rẹ ni Emanuel. Oriamọ ati oyin ni yio ma jẹ, ki o le imọ bi ati ikọ ohun ibi ati bi ati iyan ohun rere.

Ihin-rere. Luku 1. 26.

LI oṣù ẹkẹfa a sì rán angeli na Gabrieli lati ọdọ Ọlọrun lọ si ilu nla kan ni Galili, ti a npè ni Nasareti, si Wundia kan ti a fẹ fu ọkọnri kan, ti a npè ni Josefu, ti idile Dafidi; orukọ wundia na a sì ma jẹ Maria. Angeli na sì tọ ọ wá, o ni, Alafia, iwọ ẹniti a kọjusi ṣe li ore, Oluwa pẹlu rẹ: alabukún-fu ni iwọ ninu awọn obiri. Nigbati o sì ri i, ara fu u li ọrọ

Digitized by Google

rẹ̀, o sì rò ninu ara rẹ̀ pe, irú kíki kili eyi. Angeli na sì wi fu u pe, Má bẹ̀ru, Maria: nitori iwọ ti ri oju rere lọdọ Ọlọrun. Sá sì kiyesi i, iwọ o lóyun ninu rẹ, iwọ o sì bí ọmmọkọnri, iwọ o sì pè orukọ rẹ̀ ni JESU. On yio pọ̀, Ọmmọ Ọgá-ogo li a o sì ma pè e: Oluwa Ọlọrun yio sì fi itẹ́ ti Dafidi babba rẹ̀ fu u: yio sì jọbba-ni ile Jakobu titi aiye; ijọbba rẹ̀ kì yio sì ni ipẹkun. Nigbana ni Maria wi fu angeli na pe, Bawo li eyi o ha ri, nigbati emi kò ti mọ̀ ọkọnri? Angeli na sì dahùn o sì wi fu u pe, Ẹmmí Mimọ́ yio tọ̀ ọ wá, ati agbara ti Ọgá-ogo yio ṣiji bò ọ: nitorina ohun Mimọ́ ti a o ti inu rẹ̀ bí, Ọmmọ Ọlọrun li a o ma pè e. Sá sì kiyesi i, Elisabeti ara rẹ̀, o sì lóyun ọmmọkọnri li ogbologbo rẹ̀: oṣù ẹkẹfa ni fu ẹniti a npè li àgan. Nitori kò si ohun ti o ṣoro fu Ọlọrun. Maria sì wipe, Wò ọmmọbiri ọdọ ti Oluwa; ki o ri fu mi gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ̀. Angeli na sì fi i silẹ̀ lọ.

ỌJỌ TI MARKU EFANGELISTI MIMỌ́.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o fi ẹkọ́ rẹ̀ ọrun niti ipa Marku Efangelisti rẹ̀ mimọ́, kọ́ Ijọ awọn enia rẹ̀ mimọ́. Fi ore-ọfẹ́ fu wa, pe ti awa kò dabi ọmmọ kekere ti a fi gbogbo ẹfũfu ẹkọ́ asan gbá kiri, ki a le fi ẹsẹ̀ wa mulẹ̀ ninu otitọ ti Ihin-rere rẹ̀ mimọ́; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Efes. 4. 7.

FU olukuluku wa li a fi ore-ọfẹ́ fu, gẹgẹ bi oṣuwọn ti ẹbun Kristi. Nitorina o wipe,

Digitized by Google

Nigbati o ti gòke lọ si ibi giga, o ti di ijọ ti awọn igbekun ni igbekun lọ, o sì ti fi èbun fu awọn enia. (Niti pe o gòke lọ si ọrun, kini rẹ, bikọṣe pe on pẹlu ti tète sọkalẹ lọ si ìha isalẹ aiye? Ẹnikan na ti o ti sọkalẹ li o sì ti gòke lọ si ibi ti o ga jù gbogbo ọrun lọ, ki o le kún ohun gbogbo.) O sì ti fifu awọn ẹlomiran, iṣẹ Aposteli; ati fu awọn ẹlomiran, iṣẹ Woli; ati fu awọn ẹlomiran, iṣẹ Efangelisti; ati fu awọn ẹlomiran, iṣẹ Oluṣọ agutan ati iṣẹ Olukọni; lati ṣe awọn enia mimọ li aṣepé, fu iṣẹ alufa, fu imuduro ti ara Kristi: titi gbogbo wa o fi wá sinu iṣọkan ti igbagbọ, ati sinu ìmọ ti Ọmmọ Ọlọrun, si ọkọnri pipé kan, si oṣuwọn ti ọdún àgba ti o kún niti Kristi: lati isisiyi lọ ki awa ki o máṣe jẹ ewe mọ, ẹniti a o ma tì siwa tì sẹhin, ati ti a o sì ma fi gbogbo afẹfẹ ẹkọ́kẹkọ gbá kiri, nipa itanjẹ enia, ati ọgbọ́n arekereke, nipasẹ eyiti nwọn fi mba ni buba fu itanjẹ; ṣugbọn ki a ma sọ otitọ ni ifẹ, ki a le ma dàgba soke ninu rẹ li ohun gbogbo, ẹniti iṣe ori ni, ani Kristi: lati ọdọ ẹniti a fi tẹyẹtẹyẹ so gbogbo ara ṣọkan pọ, ti o sì fi ara mọra nipa eyiti a fi nkún gbogbo orike, gẹgẹ bi iṣẹ àltase na ninu oṣuwọn ni ìha gbogbo, lati ma mu ara na bisi i fu imaraduro on tikararẹ ninu ifẹ.

Ihin-rere. Joh. 15. 1.

EMI ni àjara otitọ, Babba mi sì ni oluṣọgba. Gbogbo ẹká ninu mi ti kò ba so eso, on a mu u kuro: ati gbogbo ẹká ti o ba so eso, on a sì wẹ ẹ mọ, ki o le so eso lọpọlọpọ. Ẹnyin di mimọ nisisiyi nipa ọrọ ti mo ti sọ fu nyin. Ẹ ma gbé inu mi, emi o sì ma gbé inu nyin. Gẹgẹ bi ẹká kò ti le so eso fu ara rẹ, bikọṣepe o ba ngbé inu àjara; gẹgẹ bẽli ẹnyin kò le ṣe

Digitized by Google

e, bikoṣepe ẹnyin ba ngbé inu mi. Emi ni àjara, ẹnyin ni ẹká. Ẹniti o ba ngbé inu mi, ati emi ninu rẹ, on ni yio so eso ọpọlọpọ: nitori yiyara nyin kuro lọdọ mi, ẹnyin kò le ṣe ohunkohun. Bi ẹnikan kò ba gbé inu mi, a sì mu u kuro gẹgẹ bi ẹká, ti o sì gbẹ; ti a sì kó wọn jọ, ti a sì wó wọn jù sinu iná, nwọn a sì jóna. Bi ẹnyin ba ngbé inu mi, ti ọrọ mi ba sì ngbé inu nyin, ẹnyin o bère ohun ti ẹnyin fẹ, a o sì ṣe e fu nyin. Ninu eyi li a sá nyìn Babba mi logo pe, ki ẹnyin ki o ma so eso pupọ; bẽli ẹnyin o jẹ ọmmọ ẹhin mi. Gẹgẹ bi Babba ti fẹ mi, bẽli emi sì fẹ nyin: ẹ duro ninu ifẹ mi. Bi ẹnyin ba pa ofin mi mọ, ẹnyin o duro ninu ifẹ mi; gẹgẹ bi mo ti pa ofin Babba mi mọ, mo sì duro ninu ifẹ rẹ. Nkan wọnyi ni mo sọ fu nyin, ki ayọ mi ki o le duro ninu nyin, ati ki ayọ nyin ki o le kún.

ỌJỌ TI FILIPU ATI TI JAKOBU AWỌN APOSTELI MIMỌ.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, ẹni ati mọ nitõtọ ti ṣe lye alnipẹkun; Fifu wa lati mọ Ọmmọ rẹ Jesu Kristi li amọpé, pe on ni ṣe ọna, otitọ, ati lye; pe ni ìtẹle ipasẹ ti Filipu ati Jakobu, awọn Aposteli rẹ mimọ, ki awa ki o le ma fi iduro ṣinṣin rìn li oju ọna ni ti o tẹle lye alnipẹkun; nipasẹ Ọmmọ rẹ na Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Jak. 1. 1.

JAKOBU, iranṣẹ ti Ọlọrun ati ti Jesu Kristi Oluwa, si awọn ẹya mejejila ti o túka kiri,

Digitized by Google

alafia. Ẹnyin arakọnri mi, nigbati ẹnyin ba bọ sinu onirũru idanwò, ẹ kà a si ayọ̀ gbogbo; ki ẹnyin ki o sì ma mọ̀ eyi pe, idanwò igbagbọ́ nyin ni iṣiṣẹ sũru. Ṣugbọn ẹ jẹ ki sũru ki o ṣiṣẹ aṣetan, ki ẹnyin ki o le pé, ki ẹ ṣọkan, ki o máṣe kù ohun kan. Bi ẹnikan ninu nyin ba ṣe alàìlọ́gbọn, ki o bère lọwọ́ Ọlọrun, ẹniti ifi fu gbogbo enia li ọ̀pọlọpọ, ti kì si ibaniwi; a o sì fifu u. Ṣugbọn ki o bère ni igbagbọ́, li aìṣiye-meji. Nitori ẹniti o nṣiye-meji, o dabi riruomi okun, ti nti ọwọ́ afẹfẹ bì siwa bì sẹhin. Nitoripe ki oluwarẹ̀ na ki o máṣe rò pe, on yio ri nkan gbà lọwọ́ Oluwa. Enia oniye-meji kò le mu ara duro nipa ọ̀na rẹ̀ gbogbo. Ṣugbọn ki arakọnri onirẹlẹ ki o ma yọ̀ ni ti a gbé e ga soke: ṣugbọn ọlọrọ̀, ni ti a rẹ̀ ẹ silẹ: nitori bi itan-ná koriko bẽni yio rẹ̀ silẹ fò lọ. Nitori bi õrùn ba ti là ti on ti oru mimu, a sì ma gbẹ koriko, ati itan-ná rẹ̀ a sì rẹ̀ silẹ, ati ẹwà iṣe rẹ̀ a sì parun: bẽ gẹgẹ li ọlọrọ̀ yio sì parẹ̀ nipa ọ̀na rẹ̀. Ibukún ni fu ọkọnri ti o fi ọkkàn rán idanwò: nitori igbati a ba dan a wò, yio gbà ade ìye, ti Oluwa ti ṣe ileri fu awọn ti o fẹ ẹ.

Ihin-rere. Joh. 14. 1.

EMÁṢE jẹ ki ọkkàn nyin bajẹ: ẹnyin gbà Ọlọrun gbọ́, ẹ sì gbà mi gbọ́ pẹlu. Ninu ile Babba mi ọ̀pọlọpọ ibugbe li o wà: iba máṣepe bẽni, emi iba ti sọ fu nyin. Emi nlọ lati pèse àye silẹ fu nyin. Bi emi ba sì lọ lati pèse àye silẹ fu nyin, emi yio sì tún pada wá, emi o sì mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, nibẹ̀ li ẹnyin o ma gbé pẹlu. Ẹnyin mọ̀ ibiti mo gbé nlọ, ẹnyin sì mọ̀ ọ̀na na pẹlu. Toma wi fu u pe, Oluwa, awa kò

Digitized by Google

mọ́ ibiti iwọ nlọ; awa o sì ti ṣe le mọ́ ọ̀na na? Jesu wi fu u pe, Emi li ọ̀na, ati otitọ, ati ìye: kò si ẹnikẹni ti o le wá sọdọ Babba, bikoṣe nipasẹ mi. Bi ẹnyin ba ti mọ́ mi, ẹnyin iba sì ti mọ́ Babba mi pẹlu: ati lati isisiyi lọ li ẹnyin ti mọ́ ọ, ẹnyin sì ti ri i. Filipu wi fu u pe, Oluwa, fi Babba na hàn wa, o sì to fu wa. Jesu wi fu u pe, Bi akokò ti mo ba nyin gbé ti pẹ to yi, iwọ kò sì ti imọ́ mi sibẹ, Filipi? ẹnikẹni ti o ba ti ri mi, o ti ri Babba tan; iwọ ha sì ti ṣe wipe, Fi Babba hàn wa? Iwọ kò gbagbọ́ pe, Emi wà ninu Babba, ati pe Babba wà ninu mi? ọ̀rọ ti mo sọ fu nyin, emi kò sọ̀rọ ti emi tikarami; bikoṣe ti Babba ti ngbé inu mi, on ni nṣe iṣẹ́ wọn-ni. Ẹ gbà mi gbọ́ pe, emi wà ninu Babba, ati Babba wà ninu mi: bikoṣe bẽ ẹ gbà mi gbọ́ nitoriti iṣẹ́ wọn-ni. Lõtọ, lõtọ ni mo wi fu nyin, Ẹniti o ba gbà mi gbọ́, iṣẹ́ ti mo ṣe on ni yio sì ṣe pẹlu; iṣẹ́ ti o sì tobijù wọnyi lọ ni yio sì ṣe; nitoriti emi lọ sọdọ Babba mi. Ati ohunkohun ti ẹnyin o bère li orukọ mi, on na li emi o ṣe, ki a le yìn Babba logo ninu Ọmmọkọnri. Bi ẹnyin ba bère ohunkohun li orukọ mi, emi o ṣe e.

ỌJỌ TI BARNABA APOSTELI MIMỌ́.

Adura.

OLUWA Ọlọrun Olodumare, iwọ ti o fi iyatọ èbun ti Ẹmmí Mimọ́ wọ̀ Barnaba Aposteli rẹ mimọ́; Máṣe fi wa silẹ, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, li alni ọ̀pọ̀lọpọ èbun rẹ, tabi li alsi ore-ọfẹ lati ma lò wọn nigba-gbogbo fu ọ̀lá ati ogo rẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. Iṣe 11. 22.

IHIN nkan wọnyi de etí ti ijọ awọn enia Ọlọrun ti o wà ni Jerusalemu: nwọn sì rán Barnaba, ki o lọ to bi Antioku. Nigbati o sì de ibẹ, ẹniti o sì ri ore-ọfẹ Ọlọrun, o yọ, o sì gbà gbogbo wọn niyanju pe, pẹlu ipin-nu li ọkkàn ni ki nwọn ki o fi ara mọ Oluwa. Nitori on ṣe enia rere, o sì kún fu Ẹmmí Mimọ, ati fu igbagbọ: awọn enia pipọ li a sì kà kún Oluwa. Barnaba sì dide, o lọ, si Tarsu lati wá Saulu. Nigbati o sì ri i, o mu u wá si Antioku. O sì ṣe pe o kadun kan gbako ti nwọn mba ijọ awọn enia Ọlọrun pejọ pọ, nwọn sì nkọ awọn enia pipọ. Ni Antioku ni nwọn gbé tètekọ pè awọn ọmmọ ẹhin ni Kristian. Li ọjọ wọn-ni li awọn woli si ti Jerusalemu sọkalẹ wá si Antioku. Nigbati ọkan ninu wọn, ti a npè ni Agabu sì dide, o sọtẹlẹ nipa ẹmmí pe, ọdá nla yio da ká gbogbo aiye: ti o sì ṣẹ nigba ọjọ Klaudiu Kesari. Nigbana li awọn ọmmọ ẹhin pin-nu rẹ, olukuluku bi agbara rẹ ti mọ, lati rán iranlọwọ si awọn arakọnri ti o wà ni Judea: ti nwọn sì ṣe, nwọn sì rán a lọ si awọn alàgba li ọwọ Barnaba on Saulu.

Ihin-rere. Joh. 15. 12.

EYI li ofin mi, Ki ẹnyin ki o fẹ ọmmọnikeji nyin, gẹgẹ bi mo ti fẹ nyin. Ẹnikẹni kò ni ifẹ ti o tobijù eyi lọ, pe ẹnikan fi ẹmmí rẹ lelẹ nitori awọn ọrẹ rẹ. Ọrẹ mi li ẹnyin ṣe, bi ẹnyin ba ṣe ohunkohun ti mo pa laṣẹ fu nyin. Lati isisiyi lọ emi kò pè nyin li ọmmọ ọdọ mọ; nitori ọmmọ ọdọ kò mọ ohun ti oluwa rẹ nṣe: ṣugbọn emi pè nyin li ọrẹ; nitori ohun gbogbo ti mo ti gbọ lati ọdọ Babba mi wá, mo

Digitized by Google

sì ti fi hàn fu nyin. Kì iṣe ẹnyin li o yàn mi, ṣugbọn emi li o tète yàn nyin, mo sì ṣe ìlana nyin, ki ẹnyin ki o le lọ, ki ẹ sì so eso, ki eso nyin ki o le duro; ki ohunkohun ti ẹnyin ba bère lọwọ́ Babba li orukọ mi, ki o le fi i fu nyin.

ỌJỌ TI JOHANU BAPTISTI MIMỌ́.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, nipasẹ ìpese ẹniti a fi bí Johanu Baptisti iranṣẹ rẹ ni iyanilẹnu, ti a sì rán a lati ma tún ọ̀na Ọmmọ rẹ Olugbala wa ṣe, nipa iwasu ti ironupiwada; Mu ki a ma tẹ̀le ẹkọ́ ati ìwa rẹ̀ mimọ́, ki awa ki o le ronupiwada nitõtọ gẹgẹ bi iwasu rẹ̀; ati nipasẹ apẹrẹ rẹ̀ ki a ma sọ otitọ ni itẹnumọ́ ṣinṣin, li alfoya ki a ma ba ìwa èṣẹ wi, ati ki a sì fi sũru jìya nitori otitọ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Isai. 40. 1.

ITUNU fu nyin, itunu fu nyin, enia mi li Ọlọrun nyin wi. Ẹ sọrọ itunu fu Jerusalẹmu, ki ẹ sì ke si i, Pe ìja rẹ̀ pari, pe, a dari ẹṣẹ rẹ̀ jì: nitoriti o ti gbà ago iṣẹ meji lọwọ́ Oluwa fu ẹṣẹ rẹ̀ gbogbo. Ohùn ẹniti nke li aginju, Ẹ tún ọ̀na Oluwa ṣe, ẹ mu opopo ọ̀na tọ nibi aṣalẹ fu Ọlọrun wa. Gbogbo afonifojì li a o ru soke, ati gbogbo okè nla ati okekekèke li a o tẹ́ bẹrẹ, ati ibi wiwo li a o mu tọ ati ibi palapala li a o mu ṣe titọ. A o sì fi ogo Oluwa hàn, gbogbo enia ni yio sì ri i pọ̀; nitoripe ẹnu Oluwa li ọ sọ ọ. Ohùn na wipe, Ké. On sì wipe, ki ni nke? Gbogbo enia ni

Digitized by Google

koriko, ati gbogbo ẹwà rè bi itana eweko igbẹ. Koriko a ma rọ, itana eweko a sì ma rẹ, nitoriti Ẹmmí Oluwa fẹ si i lori: nitotọ koriko li enia. Koriko a ma rọ, itana eweko a sì ma rẹ; Ṣugbọn ọrọ Olọrun wa yio duro lailai. Siọn iwọ ti nmu ihinrere wa, dide lọ si okè giga ni: Iwọ Jerusalẹmu ti nmu ihinrere wa, fi agbara gbé ohùn rẹ soke; gbé e soke, má ṣe bẹru: wi fu awọn ilunlanla Juda pe, Wò Olọrun nyin. Wò o, Olọrun Oluwa yio wá ti on ti ọwọ agbara, apa rẹ ni yio sì ma ṣe akoso fu u: kiye si i ère rẹ mbẹ pẹlu rẹ ati iṣẹ rẹ niwaju rẹ. Yio ma bọ agbo ẹran rẹ bi oluṣọ-agutan; yio sì ma fi apa rẹ ko awọn ọmmọ agutan, yio sì ma ko wọn lọ li owokan àiya rè, yio sì ma fi pẹlẹpẹlẹ dà awọn ti o loyun.

Ihin-rere. Luku 1. 57.

OJỌ Elisabeti pé wayi ti yio bí; o sì bí ọmmọkọnri. Ati awọn aladugbo, ati awọn ara rẹ gbọ́ bi Oluwa ti ṣe ãnu nla fu u; nwọn sì ba a yọ. O sì ṣe, ni ijọ ẹkẹjọ nwọn wá lati kọ ọmmọ na nila; nwọn sì sọ orukọ rẹ ni Sakaria, nipa orukọ babba rẹ. Iya rẹ sì dahùn, o ni, Bẹ̀kọ; bikoṣe Johanu li a o pè e. Nwọn sì wi fu u pe, Kò si ọkan ninu awọn ara rẹ ti a npè li orukọ yi. Nwọn sì ṣe apẹrẹ si babba rẹ, bi o ti nfẹ ki a pè e. O sì bère walã, o kọ ọ, wipe, Johanu li orukọ rẹ. Ẹnu sì yà gbogbo wọn. Ẹnu rẹ sì ṣí lọgan, okùn ahọn rẹ sì tú, a sì sọ̀rọ, o sì yìn Olọrun. Ẹru sì ba gbogbo awọn ti mbẹ li àgbegbe wọn: a sì ti rò gbogbo ihin wọnyi ká gbogbo ilẹ òke Judea. Gbogbo awọn ti o gbọ́ sì tò o sinu ọkkàn wọn, nwọn nwipe, Irú ọmmọ kili eyi o jẹ! Ọwọ́ ti Oluwa sì pẹlu rẹ. Sakaria babba rẹ si kún fu Emmí Mimọ́, o sì sọtẹlẹ, o ni, Olubukún li Oluwa

Digitized by Google

Ọlọrun Israeli; nitoriti o ti bojuwò, ti o sì ti da awọn enia rẹ̀ nide, ti o sì ti gbé iwo igbala soke fu wa ni ile Dafidi ọmmọ ọdọ rẹ̀; bi o ti wi li ẹnu awọn woli rẹ̀ mimọ́, ti nwọn ti mbẹ nigbati aiye ti ṣẹ̀: pe a o gbà wa là lọwọ́ awọn ọtá wa, ati lọwọ́ gbogbo awọn ti o korira wa; lati ṣe ãnu ti o ti leri fu awọn babba wa, ati lati ranti majẹmu rẹ̀ mimọ́; ara ti o ti bu fu Abrahamu babba wa, pe on o fifu wa, lati gbà wa lọwọ́ awọn ọtá wa, ki awa ki o le ma sìn i laìfoya, ni mimọ́ ìwa ati li ododo niwaju rẹ̀, li ọjọ́ aiye wa gbogbo. Ati iwọ, ọmmọ, woli Ọgá-ogo li a o ma pè ọ: nitori iwọ ni yio ṣaju Oluwa lati tún ọ̀na rẹ̀ ṣe; lati fi ìmọ igbala fu awọn enia rẹ̀ fu imukuro ẹ̀ṣẹ̀ wọn, nipa iyọnu Ọlọrun wa; nipa eyiti ìla õrùn lati oke wá bojuwò wa, lati fi imọlẹ fu awọn ti o joko li òkunkun ati li ojiji ikú, ati lati fi ẹsẹ̀ wa le ọ̀na alafia. Ọmmọ na sì dàgba, o sì le li ọkkàn, o sì wà ni ijù titi o fi di ọjọ́ ifihàn rẹ̀ fu Israeli.

ỌJỌ́ TI PETERU APOSTELI MIMỌ́.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, nipasẹ̀ Ọmmọ rẹ̀ Jesu Kristi iwọ ti o fi ẹ̀bun titayọ pupọ̀ fu Peteru Aposteli rẹ̀ mimọ́, ti iwọ sì fi aṣẹ fu u gidigidi pe ki o ma bọ́ agbo agutan rẹ̀; Awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ̀, mu awọn Bíṣopu ati Olutọju gbogbo lati ma wasu Ọrọ́ mimọ́ rẹ̀ li alṣemọlẹ̀, ati ki awọn enia kí o sì ma fi igbọran tẹ̀le eyi na, ki nwọn ki o le gbà ade ìye alnipẹkun, nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. Iṣe 12. 1.

LI akokò igba na ni Herodu ọbba sì nawọ́ rẹ̀ lati tọ́ awọn kan ninu ijọ awọn enia Ọlọrun. O sì fi idà bẹ́ Jakobu arakọnri Johanu lori. Nigbati o sì ri i pe, o dùn-mọ awọn Ju, o sì nawọ́ mu Peteru pẹlu. Nigbana li ọjọ alwukara. Nigbati o sì mu u, o fi i sinu tubu, o fi i le ori ẹṣọ́ mẹrin ti awọn ọmmọ ogun lọwọ́ lati pa a mọ́; o nrò pe lẹhin Irekọja, ki on ki o mu u jade tọ́ awọn enia wá. Njẹ nwọn pa Peteru mọ́ ninu tubu: ṣugbọn nwọn ngbadura fu u li alsimi si Ọlọrun ninu ijọ awọn enia Ọlọrun. Nigbati Herodu iba sì mu u jade, li oru na Peteru nsùn li arin awọn ọmmọ ogun meji ninu ìde ẹwọn meji: awọn ọmmọ ogun sì wà niwaju ilẹkun, nwọn nṣọ tubu na. Sì kiyesi i, angeli ti Oluwa duro tì i, imọlẹ si mọ́ ninu tubu: nigbati o sì lù Peteru pẹ́pẹ́ li ẹgbẹ, o gbé e dide, o ni, Dide kánkan. Ẹwọn rẹ̀ sì bọ silẹ kuro lọwọ́ rẹ̀. Angeli na sì wi fu u pe, Di àmure, ki o sì so salubata rẹ. O sì ṣe bẹ̃. O sì wi fu u pe, Da aṣọ rẹ bora, ki o sì ma tọ̀ mi lẹhin. On sì jade, o ntọ̀ ọ lẹhin lọ; kò sì mọ̀ pe otitọ li ohun na ṣe lati ọwọ́ angeli na wá; ṣugbọn o ṣebi on wà li ojuran. Nigbati nwọn kọja iṣọ ekini ati ekeji, nwọn de ẹnu ọna ilẹkun irin, ti o lọ si ilu nla; ti o sì tikararẹ̀ sí silẹ fu wọn: nigbati nwọn sì jade, nwọn nlọ titi li ọna igboro kan; lojukan na angeli na sì fi i silẹ lọ. Nigbati oju Peteru sì walẹ, o ni, Nigbayi ni mo to mọ̀ nitõtọ pe, Oluwa rán angeli rẹ̀, o sì gbà mi li ọwọ́ Herodu, ati ninu gbogbo ireti ti awọn enia Ju.

Digitized by Google

Ihin-rere. Mat. 16. 13.

NIGBATI Jesu de igberiko Kesarea ti Filipi, o bi awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ lẽre, wipe, Tali awọn enia nfi emi Ọmmọ ọkọnri ipè? Nwọn sì wi fu u pe, Omiran ni Johanu Baptisti ni iwọ; omiran wipe, Elia ni; awọn ẹlomiran ni Jeremia, bikoṣe bẽ ọkan ninu awọn woli. O bi wọn lẽre, wipe, Ṣugbọn tali ẹnyin nfi emi ipè? Simon Peteru dahùn, wipe, Kristi, Ọmmọ ti Ọlọrun alãye ni iwọ ṣe. Jesu sì dahùn o sì wi fu u pe, Alabukúnfu ni iwọ Simon Ọmmọ Jona: kì iṣe ẹran ara ati ẹ̀jẹ̀ li o sá fi eyi hàn ọ, ṣugbọn Babba mi ti mbẹ li ọrun. Ki emi ki o sì wi fu ọ pẹlu pe, Iwọ ni Peteru, lori apatta yi li emi o kọle ijọ awọn enia mi si; gbogbo agbara oju ọ̀na ọrun apadi kì yio le bori rẹ̀, emi o sì fu iwọ ni ṣika ijọbba ọrun: ohunkohun ti iwọ ba dè li aiye, a o sì dè e li ọrun: ati ohunkohun ti iwọ ba tú li aiye, a o sì tú u li ọrun.

ỌJỌ TI JAKOBU APOSTELI MIMỌ́.

Adura.

OLỌRUN alãnu, fifu wa, pe bi Jakobu Aposteli rẹ̀ mimọ́, ti fi babba rẹ̀ ati ohun gbogbo ti o ni silẹ̀, li alduro-pẹ̀ ti o sì fi igboran jẹ̀ lpe Ọmmọ rẹ̀ Jesu Kristi ti o sì tọ̀ ọ lẹhin; bẽni awa, ni ìkọ ohun aiye gbogbo ati ifẹ̀ ara silẹ̀, ki awa ki o le mura si i lati ma tọ̀ ofin mimọ́ rẹ̀ lẹhin; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

Episteli. Iṣe 11. 27, ati apakan ti Kap. 12.

LI ọjọ wọn-ni li awọn woli sì ti Jerusalemu sọkalẹ wá si Antioku. Nigbati ọkan ninu wọn, ti a npè ni Agabu sì dide, o sọtẹlẹ nipa ẹmmí pe, ọdá nla yio da ká gbogbo aiye: ti o sì ṣẹ nigba ọjọ Klaudiu Kesari. Nigbana li awọn ọmmọ ẹhin pin-nu rẹ̀, olukuluku bi agbara rẹ̀ ti mọ, lati rán iranlọwọ si awọn arakọnri ti o wà ni Judea: ti nwọn sì ṣe, nwọn sì rán a lọ si awọn alàgba li ọwọ́ Barnaba on Saulu. Li akokò igba na ni Herodu ọbba sì nawọ́ rẹ̀ lati tọ́ awọn kan ninu ijọ awọn enia Ọlọrun. O sì fi idà bẹ́ Jakobu arakọnri Johanu lori. Nigbati o sì ri i pe, o dùn-mọ awọn Ju, o sì nawọ́ mu Peteru pẹlu.

Ihin-rere. Mat. 20. 20.

NIGBANA ni iya ti awọn ọmmọ Sebede ba awọn ọmmọkọnri rẹ̀ tọ ọ wá, o bẹ̀ ẹ, o sì nfẹ ohun kan li ọwọ́ rẹ̀. O sì bi i pe, Kini iwọ nfẹ? O wi fu u pe, Jẹ ki awọn ọmmọkọnri mi mejeji ki o ma joko, ekini li ọwọ́ ọtún, ekeji li ọwọ́ òsin ni ijọbba rẹ. Ṣugbọn Jesu dahùn, o sì wipe, Ẹnyin kò mọ̀ ohun ti ẹnyin mbère. Ẹnyin le mu ninu ago ti emi o mu, ati ki a fi baptismu ti a o fi baptisti mi baptisti fu nyin? Nwọn wi fu u pe, Awa le ṣe e. O sì wi fu wọn pe, Lõtọ li ẹnyin o mu ninu ago mi, ati ninu baptismu ti a o fi baptisi mi li a o sì fi baptisi nyin; ṣugbọn lati joko li ọwọ́ ọtún ati li ọwọ́ òsin mi, kì iṣe ti emi lati fi funi, bikoṣepe kìki fu awọn ẹniti a ti pèse rẹ̀ silẹ fu lati ọdọ Babba mi wá. Nigbati awọn mẹwa iyokun gbọ́ ọ, nwọn binu si awọn arakọnri wọn mejeji. Ṣugbọn Jesu pè wọn sọdọ rẹ̀, o sì wipe, Ẹnyin mọ̀ pe awọn ọbba Keferi a ma lò agbara lori

Digitized by Google

wọn, ati awọn ẹni nla ninu wọn a ma fi ọllá tẹri wọn ba. Ṣugbọn kì yio ri bẹ̀ ninu nyin: ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba fẹ ki o pọ̀ ninu nyin, ẹ jẹ ki o ṣe iranṣẹ fu nyin; ati ẹnikẹni ti o ba fẹ ṣe olori ninu nyin, jẹ ki o ma ṣe ọmmọ ẹhin nyin: gẹgẹ bi Ọmmọ ọkọnri kò ti wá lati ma ṣe iranṣẹ fu, bikoṣe lati ma ṣe iranṣẹ funi, ati lati fi ẹmmí rẹ̀ ṣe irapada fu ọ̀pọlọpọ enia.

ỌJỌ TI BARTOLOMEU APOSTELI MIMỌ́.

Adura.

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, iwọ ti o fi ore-ọfẹ fu Bartolomeu Aposteli rẹ mimọ́ lati gbagbọ́ ati lati wasu Ọrọ rẹ nitõtọ; Fifu Ijọ awọn enia rẹ, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, lati fẹ Ọrọ mimọ́ na ti o gbagbọ́, ati lati ma wasu ki a sì ma gbà eyi na; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Iṣe 5. 12.

LI ọwọ́ awọn aposteli ni iṣẹ̀ àmi ati iṣẹ̀ iyanu pipọ ti ṣe ninu awọn enia; gbogbo wọn sì fi ọkkàn kan wà ni iloro Solomon. Ati ninu awọn iyokù, ẹnikan kò jẹ̀ daṣa ati ba wọn dàpọ: ṣugbọn awọn enia nko okiki wọn. Ọ̀pọ awọn onigbagbọ́ li a sì nyàn kún Oluwa, ati ọkọnri ati obiri. Tobẹ̃ ti nwọn ngbé awọn abirọn jade si igboro, ti nwọn ntẹ́ wọn si ori akete, ati ibĩrọgbọku, bi o tilẹ ṣe kiki ojiji Peteru ti nrekọja lọ ni ki o le ṣijibò diẹ ninu wọn. Ọ̀pọ awọn enia sì ti ilu nla igberiko wá si Jerusalemu, nwọn nmu awọn abirọn enia wá, ati awọn ti ara kan fu èṣukẹṣu: a sì ṣe dida ara olukuluku wọn.

Digitized by Google

Ihin-rere. Luku. 22. 24.

IJÀ kan sì mbẹ ninu wọn, li ẹniti yio ṣe olori ninọ wọn. O sì wi fu wọn pe, Awọn ọbba Keferi a ma lò ipá oluwa si wọn; a sì ma pè awọn ti nlò ipá ọllá si wọn ni olõre. Ṣugbọn ẹnyin kì yio sì ri bẽ: bikoṣe ẹniti o pọ̀ju lọ ninu nyin ki o jẹ bi aburo; ati ẹniti o sì ṣe ọlọllá, ki o ṣe bi iranṣẹ. Njẹ tali o pọ̀ju, ẹniti o joko tì onjẹ, tabi ẹniti o nṣe iranṣẹ? ẹniti o joko tì onjẹ kọ́? ṣugbọn emi mbẹ ninu nyin bi ẹniti nṣe iranṣẹ. Ẹnyin li awọn ti o ti mba mi gbé ninu ipọnju mi. Mo sì yàn ijọbba fu nyin, gẹgẹ bi Babba mi ti yàn ijọbba fu mi; ki ẹnyin ki o le ma jẹ, ki ẹnyin ki o sì le ma mu lori tabeli mi ni ijọbba mi, ki ẹnyin ki o le joko lori itẹ́, ati ki ẹnyin ki o le ma ṣe idajọ fu awọn ẹ̀ya Israeli mejejila.

ỌJỌ TI MATEU APOSTELI MIMỌ́.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, nipasẹ Ọmmọ rẹ olubukún iwọ ti o pè Mateu ni ibode lati ma ṣe Aposteli ati Efangelisti; Fifu wa li ore-ọfẹ lati kọ̀ gbogbo ifẹ́ ojukòkoro, ati àlfarabalẹ ifẹ́ ọrọ̀ silẹ, ati ki a ma tọ̀ Jesu Kristi Ọmmọ rẹ na lẹhin, ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu rẹ ati Ẹmmí Mimọ́, Ọlọrun kan, aiye àlnipẹkun. *Amin.*

Episteli. 2 Kor. 4. 1.

NITORINA bi awa ti ni iṣẹ alufa yi, gẹgẹ bi a sì ti ri ãnu gbà, ãrẹ̀ kò mu wa; ṣugbọn awa ti kọ̀ gbogbo ohun ìkọkọ ti o ni itiju silẹ, awa kò sì rìn li ẹ̀tan, bẽli awa kò sì fi ọwọ́

Digitized by Google

ètan mu òrọ Ọlọrun; ṣugbọn nipa fifi otitọ hàn, awa nyìn ara wa si ọkkàn olukuluku enia niwaju Ọlọrun. Ṣugbọn bi Ihin rere wa ba farasin, o farasin fu awọn ti o nù: ninu awọn ẹniti ọlọrun aiye yi ti sọ ọkkàn awọn ti kò gbagbọ́ di afọju, ki imọlẹ ti Ihin rere Kristi ti o logo, ẹniti iṣe aworan Ọlọrun, ki o máṣe mọlẹ ninu wọn. Nitoriti awa kò wasu awa tikarawa, bikoṣe Kristi Jesu Oluwa ni; awa tikarawa sì jasi iranṣẹ nyin nitori Jesu. Nitoriti Ọlọrun ẹniti o paṣẹ ki imọlẹ ki o mọlẹ lati inu òkunkun jade, on li o ti nmọlẹ li àiya wa, lati fu wa ni imọlẹ ti ìmọ ogo Ọlọrun li oju Jesu Kristi.

Ihin-rere. Mat. 9. 9.

BI Jesu sì ti nrekọja lati ibẹ̀ lọ, o ri ọkọnri kan ti a npè ni Mateu, o joko ni bode; o wi fu u pe, Ma tọ̀ mi lẹhin. O sì dide, o tọ̀ ọ lẹhin. O sì di igbati o ṣe, bi Jesu ti joko tì onjẹ, sì kiyesi i, òpọ awọn agbowode ati ẹlẹṣẹ wá, nwọn sì ba a joko pẹlu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀. Nigbati awọn Farisi sì ri i, nwọn wi fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ pe, Ẽṣe ti Olukọ nyin fi mba awọn agbowode ati awọn ẹlẹṣẹ jẹun pọ̀? Ṣugbọn nigbati Jesu gbọ́, o wi fu wọn pe, Awọn ti ara wọn le kò wá onisegun, bikoṣe awọn ti ara wọn kò da. Ṣugbọn ẹ lọ, ẹ si kọ́ bi a ti mọ̀ eyi si, Ãnu li emi o gbà, kì iṣe ẹbọ: Nitori emi kò wá lati pè awọn olododo, bikoṣe awọn ẹlẹṣẹ si ironupiwada.

Digitized by Google

ỌJỌ TI MIKAELI MIMỌ́ ATI GBOGBO AWỌN ANGELI.

Adura.

AIYE-RAIYE Ọlọrun, iwọ ti o ti ṣe ìlana ati idasilẹ lsin ti awọn Angeli ati ti enia li ẹsẹ-ẹsẹ iyani-lẹnu; Fi ãnu fifuni, pe bi awọn Angeli rẹ mimọ́ ti nṣe lsin si ọ nigba-gbogbo li ọrun, nipa ilasilẹ rẹ ki nwọn ki o le ma ràn wa lọwọ́, ki nwọn ki o sì ma dãbobo wa lori ilẹ aiye bẹ̃ gẹgẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Epistéli. Ifihàn 12. 7.

OGUN sì mbẹ li ọrun: Mikaeli pẹlu awọn angeli rẹ mba dragon na jà; ati dragon njà ati awọn angeli rẹ, nwọn kò sì le ṣẹgun; bẹ̃ni kò si àye fu wọn mọ́ li ọrun. A sì lé dragon nla na jade, ejò lailai ni, ti a npè ni Èṣu, ati Satan, ti ntàn gbogbo araiye jẹ: a sì lé e jù si ilẹ aiye, a sì lé awọn angeli rẹ jade pẹlu rẹ. Mo sì gbọ́ ohùn rara li ọrun, nwipe, Nigbayi ni igbala, ati agbara, ati ijọba ti Ọlọrun wa, ati agbara ti Kristi rẹ; nitoriti a lé olufisọ̀n ti awọn arakọnri wa sọkalẹ, ti ó nfi wọn sọ̀n niwaju Ọlọrun wa lọsán ati loru. Nwọn sì ṣẹgun rẹ nipa èjẹ ti Ọdọ Agutan ni, ati nipa ọ̀rọ ti ẹrí wọn; nwọn kò sì fẹ ẹmmí wọn titi de ikú. Nitorina ẹ ma yọ̀, ẹnyin ọrun, ati ẹnyin ti ngbé inu wọn. Egbé ni fu awọn araiye, ati fu awọn ara inu okun! nitoriti èṣu sọkalẹ tọ̀ nyin wá, ti o ni ibinu nla, nitoriti o mọ̀ pe kìki igba kukuru li on ni.

Ihin-rere. Mat. 18. 1.

LAKOKÒ na li awọn ọmmọ ẹhin Jesu tọ̀ ọ wá, nwọn bi i pe, Tali ẹniti o papọ̀ju ni

Digitized by Google

ijọbba ọrun? Jesu sì pè ọmmọ kekere kan sọdọ rẹ̀, o mu u duro larin wọn, o sì wi fu wọn pe, Lõtọ ni mo wi fu nyin, Bikoṣepe ẹnyin pada, ki ẹ sì dabi awọn ọmmọ kekere, ẹnyin kì yio le wọle ijọbba ọrun. Nitorina ẹniti o ba rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ bi ọmmọ kekere yi, on na ni yio papọ̀ju ni ijọbba ọrun. Ẹniti o ba gbà irú ọmmọ kekere yi kan, li orukọ mi, o gbà mi, ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba ṣẹ̀ ọkan ninu awọn kekere wọnyi ti o gbà mi gbọ́, o ya fu u ki a so ọlọ mọ́ ọ li ọrùn, ki a sì rì i si ibú omi okun. Egbé ni fu aiye nitori èṣẹ̀! a kò le ṣe ki èṣẹ̀ ki o má de; ṣugbọn egbé ni fu oluwarẹ̀ na nipasẹ̀ ẹniti èṣẹ̀ na ti wá! Nitorina bi ọwọ́ rẹ̀ tabi ẹsẹ̀ rẹ̀ ba mu ọ ṣẹ̀, ke wọn kuro, ki o sì mu wọn kuro lara rẹ̀; o ya fu ọ ki o ṣe akewọ, tabi akesẹ̀ lọ si ibi ìye, jù ki o li ọwọ́ meji tabi ẹsẹ̀ meji, ki a gbé ọ jù sinu iná titi aiye alnipẹkun. Bi oju rẹ̀ ba sì mu ọ ṣẹ̀, yọ ọ jade, ki o sì mu u kuro lara rẹ̀; o ya fu ọ ki o lọ si ibi ìye li olojukan, jù ki o li oju meji, ki a gbé ọ sọ sinu iná titi aiye alnipẹkun. Kiyesi ara ki ẹnyin má gàn ọkan ninu awọn kekere wọnyi; nitori mo wi fu nyin pe, Nigbagbogbo li ọrun li awọn angeli wọn nwò oju Babba mi ti mbẹ̀ li ọrun.

ỌJỌ TI LUKU EFANGELISTI MIMỌ́.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o pè Luku Onisẹgun, iyìn ẹniti mbẹ̀ ninu Ihin-rere ni, lati ṣe Efangelisti, ati Onisẹgun ti ọkkàn; Ki o le wù ọ, pe nipasẹ̀ ogùn dida ara ti ẹkọ́ rẹ̀ ti ati ọwọ́ rẹ̀ fifuni, ki gbogbo arun ọkkàn

Digitized by Google

wa ki o di awotan; nitori itoye ti Ọmmọ rẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. 2 Tim. 4. 5.

IWỌ ma ṣọra ninu ohun gbogbo, ma fi ori tì ipọnju, ma ṣe iṣẹ ti oniwasu kiri, fi idi ìsin iṣẹ alufa rẹ hàn. Nitoriti emi mura tan lati fi mi ṣe itọrẹ, igba alọ mi sì sumọ etile. Emi ti jà ìja rere, emi ti pari ipa ìlana mi, emi ti pa igbagbọ mọ: lati isisiyi lọ a ti fi ade ododo lelẹ fu mi, ti Oluwa, onidajọ ododo, yio fifu mi li ọjọ na: kì sì iṣe kìki emi nikan, ṣugbọn ati fu gbogbo awọn pẹlu ti o fẹ ifarahàn rẹ. Làkaka lati tọ mi wá nisisiyi: nitoriti Dema ti kọ mi silẹ lọ, o nfẹ aiye isisiyi, o sì lọ si Tesalonika; Kresken si Galatia, Titu si Dalmatia. Luku nikan li o kù pẹlu mi. Mu Marku wá pẹlu rẹ: nitoriti o ṣe anfani fu mi fu iṣẹ alufa na. Tikiku ni mo rán lọ si Efesu. Aṣọ igbojo ti mo fi silẹ ni Troa lọdọ Karpu, nigbati iwọ ba mbọ mu u wá, ati iwe wọn-ni, pẹlupẹlu iwe awọ wọn-ni. Aleksanderu alagbẹdẹ bàba ṣe mi ni buburu pupọ: Oluwa yio san a fu u gẹgẹ bi iṣẹ rẹ: nipasẹ ẹniti ki iwọ ki o ma ṣọra pẹlu; nitoriti o ṣe ìdena si iwasu wa pupọ.

Ihin-rere. Luku 10. 1.

OLUWA sì yàn adọrin ọmmọ ẹhin omiran pẹlu, o sì rán wọn ni mejimeji lọ si iwaju rẹ, si gbogbo ilu ati ibi, ti on tikararẹ yio gbé de. O sì wi fu wọn pe, Ikojọ-oko pọ, ṣugbọn awọn alagbaṣe kò to nkan: ki ẹnyin ki o bẹ Oluwa ti ikojọ-oko, ki o le rán awọn alagbaṣe sinu ikojọ-oko rẹ. Ẹ mu ọna nyin pọn: sawò o, emi rán nyin lọ bi ọdọ agutan sinu ikokò.

Digitized by Google

Ẹ máṣe mu asuwọn ẹ máṣe mu birigami, tabi bàta; ki ẹnyin ki o máṣe kí ẹnikẹni li ọna. Ni ilekile ti ẹnyin ba wọ, ki ẹnyin ki o tète wipe, Alafia fu ile yi. Bi ọmmọ, alafia ba mbẹ nibẹ, alafia nyin yio bà le e: bi kò ba si, yio sì tún pada si nyin. Ni ile na ni ki ẹnyin ki o gbé, ki ẹnyin ki o ma jẹ, ki ẹnyin ki o sì ma mu ohunkohun ti nwọn fifu nyin: nitori ọya alagbaṣe tọ si i.

ỌJỌ TI SIMON ATI TI JUDA AWỌN APOSTELI MIMỌ.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o fi idi Ijọ awọn enia rẹ kalẹ lori ipilẹṣẹ ti awọn Aposteli ati Woli, Jesu Kristi tikararẹ jẹ pataki okuta igọn ile; Fifu wa ki a le so wa pọ tobẽ ninu iṣọkan ẹmmí nipa ẹkọ́ wọn, ki a le sọ wa di ile tempeli mimọ́ itẹwọgbà fu ọ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Episteli. Juda 1.

JUDA, iranṣẹ ti Jesu Kristi, ati arakọnri Jakobu, si awọn ti a sọdi mimọ́ lati ọwọ́ Olọrun Babba wá, ti a sì pamọ́ ninu Jesu Kristi, ti a sì pè: Anu fu nyin, ati alafia, ati ifẹ, ki o ma bisi i. Olufẹ, nigbati mo fi alsimi gbogbo kọwe si nyin nitori igbala ti ọwọpọ, o tọ́ fu mi lati kọwe si nyin, ki emi sì gbà nyin niyanju, ki ẹnyin ki o le ma fi itara tẹnumọ igbagbọ́, ti ati fifu awọn enia mimọ́ lẽkan.

Digitized by Google

Nitoripe awọn enia kan mbẹ ti nwọn nyọ wọ̀nu li àlfarahàn, nigba atijọ ẹni ti a ti yàn si ẹbi yi, enia alàwa-bi-Ọlọrun, ti o nyi ore-ọfẹ Ọlọrun wa pada si iwọbia, ti nwọn sì nsẹ́ Oluwa Ọlọrun kanṣoṣo na, ati Jesu Kristi Oluwa wa. Nitorina emi o rán nyin letí, bi ẹnyin tilẹ ti mọ ọ lẹ̀kan, pe bi Oluwa, nigbati o gbà awọn enia là tan lati ilẹ Egipti wá, nigba ikẹhin o sì run awọn ti kò gbagbọ́. Ati awọn angẹli ti kò duro ni ipò wọn iṣaju, ṣugbọn ti nwọn fi ipò oyè wọn silẹ, awọn li o pamọ́ dè ẹ̀wọn àlnipẹkun nisalẹ òkunkun titi di ọjọ idajọ ni nla. Ani bi Sodomu ati Gomora, ati ilu agbegbe wọn wọn-ni bẹ̃ gẹgẹ, ti nwọn fi ara wọn fu àgbere iṣe, ti nwọn nlò ara òdi, awọn li o sì fi lelẹ ṣe apẹrẹ, nwọn njìya ẹsan ti iná àlnipẹkun. Bẹ̃ gẹgẹ pẹlu li awọn alalá ẹgbin wọnyi, ti nsọ ara di ẽri, ti ngàn ijoye, ati ti nwọn a ma sọ̀rọ buburu si awọn ọlọ́lá.

Ihin-rere. Joh. 15. 17.

NKAN wọnyi ni mo pa laṣẹ fu nyin pe, ki ẹnyin ki o fẹ ọmmọnikeji nyin. Bi aiye ba korira nyin, ẹnyin mọ pe o korira mi, ki o to korira nyin. Iba ṣepe ẹnyin ṣe ti aiye, aiye iba fẹ awọn ti rẹ̀: ṣugbọn nitoriti ẹnyin kì iṣe ti aiye, ṣugbọn emi ti yàn nyin kuro ninu aiye, nitorina li aiye fi korira nyin. Ẹ ranti ọ̀rọ ti mo ti sọ fu nyin pe, Ọmmọ ọdọ kò tobijù oluwa rẹ̀ lọ. Bi nwọn ba ti ṣe inunibini si mi, nwọn yio ṣe inunibini si nyin pẹlu: bi nwọn ba pa ọ̀rọ mi mọ́, nwọn yio sì pa ti nyin mọ́ pẹlu. Ṣugbọn gbogbo nkan wọnyi ni nwọn o ṣe si nyin, nitori orukọ mi, nitoriti nwọn kò mọ ẹniti o rán mi. Iba ṣepe emi kò ti wá ati sọ fu wọn, nwọn kì ba ti li ẹ̀ṣẹ: ṣugbọn nisisiyi

Digitized by Google

nwọn di alaìriwi nitori èṣẹ wọn. Ẹniti o ba korira mi korira Babba mi pẹlu. Iba ṣepe emi kò ti ṣe iṣẹ na larin wọn, ti ẹlomiran kò ṣe ri, nwọn kì ba ti li èṣẹ: ṣugbọn nisisiyi nwọn ti ri, nwọn sì korira ati emi ati Babba mi. Ṣugbọn eyi ṣe ki ọ̀rọ, ti a kọ ninu ofin wọn ki o le ṣẹ, Nwọn korira mi li alàìdi. Ṣugbọn nigbati Olutunu na ba de, ẹniti emi o rán si nyin lati ọdọ Babba wá, ani Ẹmmí otitọ ni, ẹniti nti ọdọ Babba wá, on yio sì jẽri mi: ati ẹnyin pẹlu yio sì jẽri mi, nitoriti ẹnyin ti wà pẹlu mi lati ipilẹṣẹ wá.

ỌJỌ TI GBOGBO AWỌN ENIA MIMỌ́.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, iwọ ti o ti da awọn ayanfẹ rẹ pọ̀ ninu idapọ ati ikẹgbẹ kan, li ara Ọmmọ rẹ Kristi Oluwa wa, ti o jinlẹ; Fi ore-ọfẹ fu wa bẽ lati ma tọ̀ ipasẹ awọn enia mimọ́ rẹ alabukunfu, ninu gbogbo ìwa-ọrun, ati aiye ìwa-bi-Ọlọrun, ki awa ki o le wá si ibi ayọ̀ ni ti a kò le sọ, ti iwọ ti pèse silẹ fu awọn ti o fẹ ọ laìṣẹtan; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Epistéli. Ifihàn 7. 2.

MO sì ri angeli omiran kan o nti ìha ìla õrùn jade wá, o ni èdidi ti Ọlọrun alãye lọwọ́: o sì kigbe li ohùn rara si awọn angeli mẹrin, ti a fifu lati pa ilẹ aiye ati okun lara, wipẹ, Máṣe pa ilẹ aiye, tabi okun, tabi igi lara, titi awa o fi fi èdidi sami si awọn iranṣẹ Ọlọrun wa ni iwaju

Digitized by Google

wọn. Mo sì gbọ́ iye awọn ẹniti a fi èdidi sami si: awọn ti a sami si jẹ́ ọkẹ́ meje o le ẹgbaji lati inu awọn ẹ̀ya ti awọn ọmmọ Israeli gbogbo wá. Ninu ẹ̀ya ti Juda a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Reuben a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Gadi a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Aseri a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Neftalimu a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Manase a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Simeon a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Lefi a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Isakari a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Sabulon a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Josefu a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Ninu ẹ̀ya ti Benjamin a fi èdidi sami si ẹgba mẹfa. Lẹhin eyi mo wò, sì kiyesi i, ọpọlọpọ enia, ti ẹnikẹni kò le kaye, lati inu orilẹ ède gbogbo, ati ibatan, ati enia, ati lati inu ède gbogbo wá, nwọn duro niwaju itẹ́, ati niwaju Ọdọ Agutan ni, a wọ̀ wọn li aṣọ igunwa funfun, imọ̀ ọpẹ sì mbẹ li ọwọ́ wọn; nwọn sì kigbe li ohùn rara, wipe, Igbala ni fu Ọlọrun wa ti o joko lori itẹ́, ati fu Ọdọ Agutan ni. Gbogbo awọn angeli sì duro rọgba yi itẹ́ na ká, ati yi awọn alàgba ati awọn ẹda mẹrin ni ká, nwọn sì wolẹ dojubolẹ niwaju itẹ́, nwọn sì nsìn Ọlọrun, wipe, Amin: Ibukún, ati ogo, ati ọgbọ́n, ati ọpẹ́, ati ọlá, ati agbara, ati ipá, fu Ọlọrun wa lai ati lailai. Amin.

Ihin-rere. Mat. 5. 1.

JESU nri ọpọ enia, o gùn ori òke lọ: nigbati o sì joko, awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ tọ̀ ọ wá. Nigbati o sì yà ẹnu rẹ̀, o sì nkọ́ wọn, wipe,

Digitized by Google

Alabukún-fu li awọn òtọ̀si li Ẹmmí : nitoriti nwọn ni ijọbba ọrun. Alabukún-fu li awọn ẹniti nkãnu : nitoriti a o tù wọn ninu. Alabukún-fu li awọn ọlọkkàn tutù : nitoriti nwọn o jogún aiye. Alabukún-fu li awọn ẹniti ebi npa ati ti ongbẹ ngbẹ sipa ododo ; nitoriti a fi kún wọn. Alabukún-fu li awọn alãnu : nitoriti nwọn o ri ãnu gbà. Alabukún-fu li awọn oninu funfun : nitoriti nwọn o ri Ọlọrun. Alabukún-fu li awọn onilaja : nitori awọn ọmmọ Ọlọrun ni a o ma pè wọn. Alabukún-fu li awọn ẹniti a nṣe inunibini si nitori ododo : nitoriti nwọn ni ijọbba ọrun. Alabukún-fu li ẹnyin, nigbati nwọn ba nkẹgan nyin, ti nwọn ba nṣe inunibini si nyin, ti nwọn ba nfi eke sọ̀rọ buburu gbogbo si nyin nitori emi. Ẹ ma yọ̀, ki ẹnyin ki o sì ma yọ̀ ayọ̀ nla : nitoriti ère nyin pọ̀ li ọrun : bẹ̃ni nwọn sá ṣe inunibini si awọn woli ti o ti mbẹ ṣaju nyin.

Digitized by Google

IṢẸ́ IPINFUNI TI ONJẸ ALẸ OLUWA

TABI TI

IDAPỌ MIMỌ́.

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọ̀wọ li orukọ rẹ. Ijọbba rẹ de. Ifẹ́ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ọjọ wa loni. Dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa, Bi a ti ndari ẹ̀ṣẹ jì awọn ti o ṣẹ̀ wa. Má fà wa sinu idẹwò; Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin. Nitori ijọbba ni ti rẹ, agbara ni ti rẹ, ogo ni ti rẹ, lailai. Amin.

Adura.

OLỌRUN Olodumare, ẹniti gbogbo àiya wa ṣipaya fu, ẹniti gbogbo ifẹ́ inu wa di mimọ́ fu, ati ẹniti ohun ìkọkọ kan kò fi ara pamọ́ lọdọ rẹ; Fi imísi ti Ẹmmí Mimọ́ rẹ wẹ̀ ìro inu wa nù, ki awa ki o le ma fẹ ọ li afẹtan, ki a sì le ma gbé Orukọ mimọ́ rẹ ga bi o ti yẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Alufa. Ọlọrun sọ gbogbo ọ̀rọ wọnyi, pe; Emi ni JEHOFA Ọlọrun rẹ: Iwọ kò gbọdọ li ọlọrun omiran pẹlu mi.

Idahùn. Oluwa, ṣãnu fu wa, ki o sì yi wa li àiya pada, ki a le pa ofin yi mọ́.

Alufa. Iwọ kò gbọdọ yá ere-kere fu ara rẹ, tabi aworan ohun kan ti mbẹ li oke ọrun, tabi ti ohun kan ti mbẹ ni isalẹ ilẹ, tabi ti

Digitized by Google

ohun kan ti mbẹ ninu omi ni isalẹ ilẹ. Iwọ kò gbọdọ tẹ ori rẹ ba fu wọn, bẽni iwọ kò gbọdọ sìn wọn: nitori Emi JEHOFA Ọlọrun rẹ Ọlọrun owú ni mi, ti mbẹ̀ ẹ̀ṣẹ awọn babba wò lara awọn ọmmọ, lati iran-diran ẹkẹta ati ẹkẹrin ninu awọn ti o korira mi, Emi a sì ma fi ãnu hàn ẹgbẹgbẹrun awọn ti o fẹ mi, ti nwọn sì pa ofin mi mọ́.

Idahùn. Oluwa, ṣãnu fu wa, ki o sì yi wa li àiya pada, ki a le pa ofin yi mọ́.

Alufa. Iwọ kò gbọdọ pè Orukọ JEHOFA Ọlọrun rẹ lasan: nitori ti JEHOFA kì yio mu awọn ti o pè Orukọ rẹ̀ lasan, li aìlẹ̀ṣẹ̀ li ọrùn.

Idahùn. Oluwa, ṣãnu fu wa, ki o sì yi wa li àiya pada, ki a le pa ofin yi mọ́.

Alufa. Ranti ọjọ Isimi lati lò o ni mimọ́. Ijọ mẹfa ni iwọ o ṣiṣẹ, ti iwọ o sì ṣe iṣẹ́ rẹ gbogbo; ṣugbọn ijọ ekeje li ọjọ Isimi JEHOFA Ọlọrun rẹ. Ninu rẹ̀ iwọ kò gbọdọ ṣe iṣẹ́-kiṣẹ kan, iwọ, tabi ọmmọ rẹ ọkọnri, tabi ọmmọ rẹ obiri, tabi ọmmọ ọdọ rẹ ọkọnri, tabi ọmmọ ọdọ rẹ obiri, tabi ohun ọsin rẹ, tabi alejò rẹ ti o mbẹ ninu ibode rẹ. Nitori ni ijọ mẹfa ni JEHOFA da ọrun on aiye, okun, ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu wọn, o sì simi ni ijọ ekeje: nitori na ni JEHOFA ṣe busi ọjọ isimi, o sì yà a si mimọ́.

Idahùn. Oluwa, ṣãnu fu wa, ki o sì yi wa li àiya pada, ki a le pa ofin yi mọ́.

Alufa. Bọwọ fu babba on iya rẹ: ki ọjọ rẹ ki o le pẹ ni ilẹ, ti JEHOFA Ọlọrun rẹ fifu ọ.

Idahùn. Oluwa, ṣãnu fu wa, ki o sì yi wa li àiya pada, ki a le pa ofin yi mọ́.

Alufa. Iwọ kò gbọdọ pania.

Idahùn. Oluwa, ṣãnu fu wa, ki o sì yi wa li àiya pada, ki a le pa ofin yi mọ́.

Alufa. Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga.

Digitized by Google

Idahùn. Oluwa, ṣãnu fu wa, ki o sì yi wa li àiya pada, ki a le pa ofin yi mọ́.

Alufa. Iwọ kò gbọdọ jale.

Idahùn. Oluwa, ṣãnu fu wa, ki o sì yi wa li àiya pada, ki a le pa ofin yi mọ́.

Alufa. Iwọ kò gbọdọ jẽri eke si ẹnikeji rẹ.

Idahùn. Oluwa, ṣãnu fu wa, ki o sì yi wa li àipa pada, ki a le pa ofin yi mọ́.

Alufa. Iwọ kò gbọdọ ṣojukòkoro si ile ẹnikeji rẹ, iwọ kò gbọdọ ṣojukòkoro si aya ẹnikeji rẹ, tabi ọmmọ ọdọ rẹ̀ ọkọnri, tabi ọmmọ ọdọ rẹ̀ obiri, tabi malu rẹ̀, tabi kẹtẹkẹtẹ rẹ̀, tabi ohun gbogbo ti ṣe ti ẹnikeji rẹ̀.

Idahùn. Oluwa, ṣãnu fu wa, ki o sì kọ gbogbo ofin rẹ wọnyi si wa li àiya, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ.

¶ *Nigbana li Alufa o gbà ọkan ninu awọn Adura meji fu Ọbba, o sì wipe,*

Ẹ jẹ ki a gbadura.

OLỌRUN Olodumare, ijọba ẹniti kò nipẹkun, ati agbara ẹniti kò li opin; Ṣãnu fu gbogbo Ijọ awọn enia rẹ; ki iwọ ki o sì ṣe akoso àiya N— Ọbba (Bãlẹ) Iranṣẹ ayanfẹ rẹ, (bi o ti nmọ̀ iranṣẹ ẹniti on ṣe) ki o le ma tọju ọlá ati ogo rẹ jù ohun gbogbo lọ: ati ki awa, ati gbogbo awọn enia rẹ̀ (ti awa sì nrò bi o ti yẹ, ọlá ẹniti o ni) ki a ma fi otitọ sìn i, ki a ma bu ọlá fu u, ki a sì ma fi iparamọ gbà ti rẹ̀ gbọ́, nipa ti rẹ, ati nitori ti rẹ, gẹgẹ bi Ọrọ ati ìlana rẹ ti o ni ibukún; nitori Jesu Kristi Oluwa wa, ẹniti o wà ti o sì njọba pẹlu iwọ ati Ẹmmí Mimọ́, lai Ọlọrun kan, aiye ailopẹkun. *Amin.*

Digitized by Google

Tabi eyi.

OLỌDUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, ninu Ọ̀rọ̀ mímọ́ rẹ̀ li a gbé ti kọ́ wa pe, àiya awọn Ọbba mbẹ̀ ni ikawọ ati akoso rẹ̀, ati pe iwọ̀ ṣe fà wọn, ti iwọ̀ sì ṣe yi wọn pada bi o ti tọ́ julọ̀ si ọgbọ́n rẹ̀ bi-ti-Ọlọrun: Awa nfi iparamọ̀ bẹ̀bẹ̀ lọdọ̀ rẹ̀ lati fà ati lati ṣe akosò àiya N— Ọbba (Bãlẹ̀) bẹ̃, Iranṣẹ̀ rẹ̀, ni ìro inu, ọ̀rọ̀, ati iṣẹ́ rẹ̀ gbogbo, ki o le ma tọju ọ̀llá ati ogo rẹ̀, ki o sì le ma humọ̀ ati pa awọn enia rẹ̀ mọ́ ti a fi si iṣọ́ rẹ̀, li ọ̀rọ̀, li alafia, ati ni lwa-bi-Ọlọrun: Fi eyi fu ni, Babba alãnu, nitori ti Ọmmọ̀ rẹ̀ ọwọn, Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

¶ *Nigbana li Alufa o gbà Adura ti a yàn silẹ̀ fu Ijọ Ọlọrun na.*

MO gbà Ọlọrun kan Babba Olodumare gbọ́, Ẹlẹda ọrun on aiye, Ati ohun gbogbo ti a nri ati eyi ti a kò ri.

Mo gbà Oluwa kan gbọ́ Jesu Kristi, Ọmmọ̀ bíbi nikanṣoṣo Ọlọrun, Ti a bí lati ọdọ̀ Babba rẹ̀ ṣaju aiye gbogbo, Ọlọrun lati inu Ọlọrun, Imọlẹ̀ lati inu Imọlẹ̀, Ọlọrun tikararẹ̀ lati inu Ọlọrun tikararẹ̀, Ẹniti a bí, ti a kò da, Ẹniti ṣe ara kan na pẹlu Babba; Lati ọwọ́ ẹniti a ti da ohun gbogbo, Ẹni nitori awa enia, ati nitori igbala wa, ti o ti ọrun wá ilẹ̀, Ẹniti o sì mu awọ̀ ara nipa Ẹmmí Mímọ́ lara Maria Wundia, A sì da a li ọkọnri, A sì kàn a mọ́ agbelebu pẹlu, nitori wa lọwọ́ Pontiu Pilatu. O jìya a sì sin i, Ni ijọ ẹkẹta o sì tún jinde gẹgẹ bi Ọ̀rọ̀ Ọlọrun, O sì lọ soke ọrun, O sì joko li ọwọ́ ọtún Babba. Yio sì tún pada wá ti on ti ogo lati ba ati ãye ati okú wijọ: Ijọbba ẹniti kì yio nipẹkun.

Digitized by Google

Mo sì gbà Ẹmmí Mimọ́ gbọ́, Oluwa ati Olufuni ni ìye, Ẹniti nti ọdọ Babba ati Ọmmọ wá, Pẹlu Babba ati Ọmmọ ẹniti a nsìn ati ti a nyìn logo pọ̀. Ẹniti o ti ẹnu awọn Woli sọ̀rọ. Mo sì gbà Ijọ mimọ́ kan ti awọn enia Ọlọrun ati ti awọn Aposteli gbọ́. Mo jẹwọ Baptismu kan fu imukuro ẹ̀ṣẹ̀, Emi sì nreti ajinde okú, Atì ìye aiye ti mbọwá. Amin.

¶ *Nigbana li Alufa o kà diẹ ninu awọn ỳrọ Ọlọrun nwọnyi,*

ENYIN jẹ ki imọlẹ nyin ki o mọlẹ tobẹ̃ niwaju enia, ki nwọn ki o le ma ri iṣẹ́ rere nyin, ki nwọn ki o sì le ma yìn Babba nyin ti mbẹ li ọrun logo. *Mat.* 5. 16.

Ẹnyin máṣe tò iṣura jọ fu ara nyin li aiye, nibiti kòkoro ati ipara ṣe bà a jẹ, ati nibiti awọn olè runlẹ, ti nwọn sì jale: ṣugbọn ẹ kó iṣura jọ fu ara nyin li ọrun, nibiti kòkoro ati ipara kò le bà a jẹ, ati nibiti awọn olè kò le runlẹ ki o jale. *Mat.* 6. 19, 20.

Ohun-kohun ti ẹnyin nfẹ ki awọn enia ki o ṣe si nyin, bẽni ki ẹnyin ki o sì ṣe si wọn gẹgẹ: nitori eyi li ofin ati awọn woli. *Mat.* 7. 12.

Kì iṣe gbogbo ẹniti npè mi li Oluwa, Oluwa, ni yio wọle ijọba ọrun; bikoṣe ẹniti nṣe ifẹ́ ti Babba mi ti mbẹ li ọrun. *Mat.* 7. 21.

Sakeu dide duro, o sì wi fu Oluwa pe; Sa wò o, Oluwa, àbọ ohun ini mi ni mo fi tọrẹ fu awọn olupọnju; bi mo ba sì fi ẹ̀sun eke gbà ohun kan lọwọ́ ẹnikẹni, mo san a pada ni mẹrinmẹrin. *Luku* 19. 8.

Tani lọ si ogun nigba kan ni inawo ara rẹ̀? tani gbìn agbala ajara, ti kì sì jẹ eso inu rẹ̀?

Digitized by Google

tabi tani bọ́ ọwọ ẹran, ti kì sì jẹ ninu wàra ọwọ ẹran na? 1 *Kor.* 9. 7.

Bi awa ti fọnrugbin ohun ti ẹmmí si nyin, ohun nla ha ni bi awa o sì ká ohun nyin ti ṣe ti aiye? 1 *Kor.* 9. 11.

Ẹnyin kò mọ́ pe, awọn ti nṣe iranṣẹ nipa ohun mimọ́, ninu ohun ti ibi mimọ́ ni nwọn njẹ? ati awọn ti o duro ti pepele, pepele ni nwọn mba ṣe olupin? Gẹgẹ bẹ̌ li Oluwa sì lana silẹ, pe awọn ti nwasu Ihin-rere, ohun Ihin-rere ni ki nwọn ki o ma jẹ. 1 *Kor.* 9. 13, 14.

Ẹniti o ba fọnrugbin kiun, kiun ni yio sì ká; ẹniti o ba sì fọnrugbin pupọ̀, pupọ̀ ni yio sì ká. Jẹ ki olukuluku enia ki o ṣe gẹgẹ bi o ti wù u li ọkkàn rẹ̀, kì iṣe afinyanju ṣe, tabi ti alàgbọdọ́ máṣe; nitori ti Ọlọrun fẹ oninudidùn ọlọrẹ. 2 *Kor.* 9. 6, 7.

Ki ẹniti a nkọ́ ninu Ọ̀rọ̀ na ki o pèse fu ẹniti nkọni ninu ohun rere gbogbo. Ki a máṣe tàn nyin jẹ, a kò le gàn Ọlọrun: nitori ohunkohun ti enia ba fọnrugbin on ni yio sì ká pẹlu. *Gal.* 6. 6, 7.

Njẹ bi awa ti ni igba, ẹ jẹ ki a ṣore fu gbogbo enia, ati pẹlu-pẹlu fu awọn arale igbagbọ́. *Gal.* 6. 10.

Ṣugbọn ìwa-bi-Ọlọrun pẹlu ikún-ni-loju èrè nla ni: nitori ti awa kò mu ohun kan wá si aiye yi, o sì daniloju pe awa kì yio sì le mu ohun kan ti inu rẹ̀ jade lọ. 1 *Tim.* 6. 6, 7.

Kìlọ fu awọn ti o lọrọ̀ li aiye yi, ki nwọn ki o mura ati ṣe itọrẹ, ki inu wọn ki o sì ma dùn lati pinfuni; ki nwọn ki o ma kó iṣura ipilẹ rere jọ fu ara wọn dè igba ti mbọ̀, ki nwọn ki o le de ibi ìye ti kò nipẹkun. 1 *Tim.* 6. 17, 19.

Ọlọrun kì iṣe alàṣododo, ti yio gbagbé iṣẹ́

Digitized by Google

ati lãlã ifẹ́ nyin, ti ẹnyin ti fi hàn sipa Orukọ rẹ̀, niti ẹnyin ti nṣe iranṣẹ fu awọn enia mimọ́, ti ẹ sì nṣe sibẹ̀. *Heb.* 6. 10.

Ati ma ṣore, on ati ma pinfuni, ẹ máṣe gbagbé: nitori pe irú ẹbọ bẹ̃ni inu Ọlọrun dùn si jọjọ. *Heb.* 13. 16.

Ẹniti o ba ni ohun rere aiye yi, ti o sì ri arakọnri rẹ̀ ti ṣe alaìni, ti o sì sé ilẹkun iyọnu rẹ̀ mọ́ ọ, ifẹ́ Ọlọrun yio ha ti ba oluwarẹ̀ gbé? 1 *Joh.* 3. 17.

Ẹniti o ba ṣãnu fu olupọnju JEHOFA li o win: ati ohun ti o fifuni yio san a pada fu u. *Pro.* 19. 17.

Ibukún ni fù ẹniti npèse fu olokurun ati fu alaìni: JEHOFA yio gbà a là nigba ipọnju. *Psal.* 41. 1.

¶ *Ẹ jẹ ki a gbadura fu gbogbo ìwa ajagun ti Ijọ awọn enia Kristi li aiye yi.*

OLODUMARE ati lai Ọlọrun alãye, iwọ ti o ti ọwọ́ Aposteli rẹ̀ mimọ́ kọ́ wa lati ma gbadura, ati lati ma bẹbẹ, ati lati ma dupẹ nitori gbogbo awọn enia; Awa nfi iparamọ bẹbẹ lọdọ rẹ̀, ki iwọ ki o fi ãnu rẹ̀ ti o julọ (*gbà ọrẹ ãnu ati ẹbun wa, ati ki o sì*) * gbà adura wa wọnyi, ti awa ngbà si Ọlá-nla Ìwa mimọ́ rẹ̀; awa mbẹbẹ lọdọ rẹ̀, ki iwọ ki o ma mí ẹmmí otitọ, iṣọkan, ati irẹpọ̀, nigba-gbogbo si gbogbo Ijọ awọn enia mimọ́ rẹ̀: Ki iwọ ki o sì fifuni, ki gbogbo awọn ti o jẹwọ Orukọ mimọ́ rẹ̀, ki nwọn ki o ṣe ohùn kan li otitọ ti Ọrọ mimọ́ rẹ̀, ki nwọn ki o sì wà ni iṣọkan, ati ni ifẹ́ bi-Ọlọrun. Awa sì mbẹbẹ lọdọ rẹ̀ lati gbà, ati lati dãbobo awọn Ọbba, Ọmmọ

* *Bi ọrẹ ãnu tabi ẹbun kò ba si, a o fò ọrọ nwọnyi* (gbà ọrẹ ãnu ati ẹbun wa) *li aìka.*

Digitized by Google

alade, ati Bãlẹ gbogbo ti ṣe Kristian; ṣugbọn pẹlu-pẹlu N— Ọbba wa Iranṣẹ rẹ; ki a le ma fi ìwa-bi-Ọlọrun ati ìwa pẹlẹ ṣe akoso wa labbẹ oyè rẹ: Ki iwọ ki o sì fifu gbogbo awọn Ìgbimọ rẹ, ati fu gbogbo awọn ti a fi sì ibi ọllá labbẹ oyè rẹ, ki nwọn ki o le ma fi otitọ, alṣojusaju dajọ alṣegbe, lati ṣẹ ìwa-buburu ati ìwa-èṣẹ nisẹ, ati lati gbé ìsin otitọ rẹ ati ìwa rere ọrun leke. Babba ọrun, fi ore-ọfẹ fu gbogbo awọn Olori alufa, ati fu awọn alufa, ki nwọn ki o le ma fi ìwa ati ẹkọ́ wọn gbé Ọrọ rẹ otitọ ti o ni ìye kalẹ, ati bi o ti tọ́ ati bi o ti yẹ ki nwọn ki o le ma ṣe iṣẹ́ ipinfuni awọn Sakramenti rẹ mimọ́: Ati ki o sì fi ore-ọfẹ rẹ ọrun fu gbogbo awọn enia rẹ; ati pẹlu-pẹlu fu ijọ awọn enia ti o wà nihin nisisiyi; pẹlu àiya tutù ati ọ̀wọ ti o yẹ, ki nwọn ki o ma gbọ́, ki nwọn ki o sì ma gbà Ọrọ mimọ́ rẹ; ki nwọn ki o ma sìn ọ nitõtọ ni mimọ́ ìwa ati li ododo li ọjọ aiye wọn gbogbo. Awa sì nfi iparamọ bẹbẹ lọdọ rẹ ninu ore rẹ, Oluwa, lati rẹ on ati ràn gbogbo wọn lọwọ́ li aiye irekọja yi, ẹniti o wà ninu iṣẹ́, ni ibinujẹ, li alàni, ninu arùn, tabi ninu ipọnju omiran. Awa sì nfi ibukún fu Orukọ mimọ́ rẹ pẹlu, nitori gbogbo awọn enia rẹ ti o ti fi aiye yi silẹ, ni igbagbọ́, ati ni ìbẹru rẹ; awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o fi ore-ọfẹ fu wa bẹ̀, lati ma tọpa ìwa rere wọn, ati pẹlu wọn ki awa ki o le ṣe onipin ijọbba ọrun rẹ: Babba fi eyi fu ni, nitori Jesu Kristi Onilaja ati Alagbawi wa nikanṣoṣo. *Amin.*

Iyanju.

OLUFẸ ọwọn, ni ijọ —— oni, emi ngbèro, nipa iranlọwọ Ọlọrun, lati ṣe ipinfuni Sakramenti ti Ara on Ẹjẹ Kristi ti o ni itunu

Digitized by Google

julọ, fu gbogbo iwọn ẹniti ọkkàn wọn ba fà si ni ifọkkàn sìn Ọlọrun; lati fi ọwọ́ wọn gbà a ni iranti ti Agbelebu ati Ìya rẹ̀ ti o toye; nipa eyi kan na ti awa gbé nri imukuro ẹ̀ṣẹ̀ wa gbà, ti a sì nmu wa di onipin ti ijọbba ọrun. Njẹ nitori na iṣẹ́ wa ni lati fi iparamọ ati tọkkàn-tọkkàn dupẹ bi o ti tọ́ julọ fu Ọlọrun Olodumare Babba wa ti mbẹ li ọrun, nitori ti o fi Jesu Kristi Ọmmọ rẹ̀ Olugbala wa fu ni, kì iṣe kìki ati kú fu wa, ṣugbọn pẹlu lati ma ṣe onjẹ ati ohun ibọ-ni ti ẹmmí ni Sakramenti na mimọ́. Eyi ti ṣe ohun mimọ́ ati ohun itunu fu awọn ẹniti o gbà a bi o ti yẹ, bẹ̃ li o sì ṣe ohun ewu fu awọn ti o sì làkaka wá lati gbà a lalẹ; iṣẹ́ mi ni ki emi gbà nyin niyanju niwọyi lati rò ọllá-nla ti ọrọ ijinlẹ na mimọ́, ati ewu nla ti algba a bi o ti yẹ; bẹ̃ni ki ẹnyin ki o sì wá ọkkàn nyin jalẹ koro, (kì ima ṣe ni iwá afọwọ-ta, bi awọn ẹlẹ̀tan niwaju Ọlọrun; ṣugbọn bẹ̃) ki ẹnyin ki o le wá ni mimọ́ ati li allẽri si irú Ase ọrun yi, ninu aṣọ iyawo ti Ọlọrun nwá sinu Ọrọ mimọ́ rẹ̀, ki a sì le gbà nyin ni alabapin ti o yẹ si ibi Tabeli na mimọ́.

Ọna ati ipa ati wá sibẹ̀ ni i; Àtetekọṣe, ki ẹnyin ki o fi ìlana ti ofin Ọlọrun wadi ìwa ati ọrọ ẹnu nyin; nibi-kibi ti ẹnyin ba sì woye pe ẹnyin tikara nyin ti ṣẹ̀, iba ṣe nipa ifẹ́, nipa ọrọ ẹnu, tabi nipa ìwa hihù, nibẹ̀ ni ki ẹnyin ki o pohunrere ẹkún ọpọlọpọ ẹ̀ṣẹ̀ ara nyin, ki ẹnyin ki o sì jẹwọ ẹ̀ṣẹ̀ ara nyin fu Ọlọrun Olodumare, pẹlu ipin-nu ti ìwa rere apada-hù. Bi ẹnyin ba sì woye pe ẹ̀ṣẹ̀ nyin kì iṣe si kìki Ọlọrun nikan, ṣugbọn si ẹnikeji nyin pẹlu; njẹ ki ẹnyin ki o ba ara nyin làja; ki ẹnyin ki o sì mura ati san ẹsan pada ati lati ṣe itunu bi agbara nyin ti gùn to, nitori ohun ibajẹ

Digitized by Google

ati iwọsi ti o ti ọdọ nyin ṣe si ẹlomĩ; ki ẹnyin ki o sì ma mura bẹ̃ gẹgẹ lati dari jì awọn ẹlomĩ ti nwọn sì ti ṣè si nyin, bi ẹnyin ti nfẹ idariji èṣẹ nyin lọwọ́ Ọlọrun: nitori bi kò ba ri bẹ̃ gbigbà ti Onjẹ Idapọ mimọ́ na, kì yio ṣe ohun omiran bikoṣepe ki o sọ ẹbi nyin di pupọ̀: Nitorina bi ẹnikan ninu nyin ba nṣe asọrọ òdi si Ọlọrun, adèna, tabi aṣe ibajẹ Ọrọ rẹ̀, àgbere, tabi ti nṣe arankan, tabi ilara, tabi ti o wà ninu èṣẹ buburu omiran, ẹnyin ronupiwada èṣẹ nyin, bikoṣe bẹ̃, ẹ máṣe wá si ibi Tabeli na mimọ́; lẹhin igbati ẹnyin ba gbà Sakramenti mimọ́ na tan, ki èṣu ki o má wọ̀ inu nyin, bi o ti wọ̀ inu Juda, ki o má sì ṣe mu nyin kún fu èṣẹ gbogbo, ki o má sì ṣe mu nyin ati ara ati ọkkàn lọ si inu iparun.

Ati itori ti o sì yẹ, pe ẹnikẹni kò gbọdọ wá si ibi Idapọ mimọ́ na, bikoṣepe ni igbẹkẹle ãnu Ọlọrun pupọ̀, ati pẹlu ibalẹ ọkkàn; nitori na bi ẹnikan ba mbẹ ninu nyin, ti kò le fi eyi mu ọkkàn rẹ̀ balẹ, bi o ba nfẹ itunu ati ìmọ omiran si i, ki o tọ̀ mi wá, bi kò sì ṣe bẹ̃, ki o tọ̀ Alufa omiran ti Ọrọ Ọlọrun lọ, ti o moye, ti o kọ́-ẹkọ, ki o sì ṣí ibinujẹ rẹ̀ silẹ fu u, nipa isọ Ọrọ mimọ́ Ọlọrun, ki o le ri anfani ifiji èṣẹ, pẹlu ìmọ ati ẹkọ́ ẹmmí, lati mu ọkkàn rẹ̀ balẹ, ati lati yẹ onnọ́ ati iṣiye-meji kuro.

Tabi Iyanju yi.

ARA olufẹ ọwọn, ni ijọ —— oni, emi nrò o, nipa ore-ọfẹ Ọlọrun, lati ṣe ipinfuni ti Onjẹ Oluwa: nitori ti Ọlọrun, li emi npè gbogbo ẹnyin ti o wà nihinyi, ki ẹnyin ki o wá sibẹ̀; mo sì bẹ̀ nyin, nitori Jesu Kristi Oluwa, ki ẹnyin ki o máṣe kọ̀ lati wá sibẹ̀, bi Ọlọrun tikararẹ̀ ti nfi ifẹ́ rẹ̀ pè ni. Ẹnyin mọ̀ bi o ti ṣe ohun ibinujẹ ati àbukun si, nigbati

Digitized by Google

enia kan ba sè àse pupọ̀, ti o fi onirũru onję ṣe tabeli rę̀ li ọṣọ́, ti kò si ohun ti o kù, bikoṣepe, ki awọn, ti a pè ki o joko; ṣugbọn ki awọn ti a pè (laìni idi) laìmore tobẽ, ki nwọn ki o kọ̀ lati wá. Tani ninu nyin ti inu rę̀ kì yio ru? Tani kì yio rò pe àbukun ati iwọsi nla li a ṣe si on? Nję nitori na, ęnyin olufę ọwọn julọ nipa ti Kristi, ę ma kiye si ara nyin rere, ni ifasę sęhin kuro nibi Onję mimọ́ yi, ki ęnyin ki o máṣe ru ibinu Ọlọrun si ara nyin. Kò ṣoro fu ęnikan lati wi pe, Emi kì yio ję onję idapọ, nitori ti iṣẹ́ aiye di mi lọwọ́. Ṣugbọn irú awawi wọn-ni kò le kọja, kò sì le ṣe ohun amoju-kuro bẽ niwaju Ọlọrun. Bi ęnikan ba sì wipe, ęlęṣę buburu li emi, nitori na ni mo ṣe bę̀ru ati wá: ẽhaṣe ti ęnyin kò ronupiwada ki ęnyin ki o sì mu ìwa rere atun-hù? Nigbati Ọlọrun npè nyin, oju kò tì nyin lati wipe ęnyin kò fę wá? Nigbati ęnyin o ba pada tọ̀ Ọlọrun lọ, ęnyin o le ṣe awawi fu ara nyin pe, ęnyin kò ti mura tan? Ęnyin ba ara nyin rò o gidigidi bi irú awawi ę̀tan ni kì yio ti ṣe anfani niwaju Ọlọrun. Awọn ti o kọ̀ àse ninu Ihin-rere, nitori ti nwọn rà ilę oko, tabi awọn ti nfę lọ dan àjaga malu wò, tabi awọn ti agbeyawo fu, a kò fi awawi wọn jì wọn, ṣugbọn a kà wọn li alaìyę si àse ọrun.

Nipa ti emi, emi o mura; ati gęgę bi iṣẹ́ Oyè mi, mo pè nyin li Orukọ Ọlọrun, mo pè nyin fu Kristi, emi ngbà nyin niyanju, bi ęnyin ti fę igbala ọkkàn ara nyin, ki ęnyin ki o ṣe alabapin Idapọ mimọ́ yi. Ati bi Ọmmọ Ọlọrun ti fiyesini lati fi ikú jọwọ ọkkàn rę̀ lọwọ́ nitori igbala nyin lori Agbelebu; iṣẹ́ nyin sì ni bẽ lati gbà Idapọ na ni iranti ębọ ikú rę̀, bi on tikararę̀ ti fi ohùn silę: bi ęnyin ba sì gbagbé ati ṣe ohun na, ki ęnyin ki o rò

Digitized by Google

o ninu ara nyin bi àbukun ti ẹnyin ṣe si Ọlọrun ti tobi to, ati bi lya ti ẹnyin o jẹ nitori na ti o so-rọ̀ li ori nyin ti pọ̀ to; nigbati ẹnyin ba fi amọṣe fà sẹhin kuro nibi Tabeli Oluwa, ti ẹnyin sì yà ara nyin kuro lọdọ awọn arakọnri nyin, ti o wá lati fi àse ọrun na ti o julọ bọ́ ara wọn. Bi ẹnyin ba rò nkan wọnyi gidigidi, nipa ore-ọfẹ Ọlọrun ẹnyin o pada si ironu ti o sanju: nitori ati ri i gbà na, awa kì yio simi ati ma fi iparamọ bẹ̀bẹ lọdọ Ọlọrun Olodumare Babba wa ti mbẹ li ọrun.

Iyanju ni igba ti Sakramenti.

OLUFẸ ọwọn nipa ti Oluwa, ẹnyin ti nfẹ wá si Idapọ mimọ́ ti Ara on Ẹjẹ Kristi Olugbala wa, ki o rò bi Paulu ti gbà gbogbo enia niyanju lati wadi ara wọn jalẹ koro, ki nwọn ki o to làkaka lati wá jẹ Akara na, ati lati wá mu ninu Ago na. Nitori bi anfani rẹ̀ ti pọ̀ to, bi awa ba fi ironupiwada àiya nitõtọ ati ãye igbagbọ́ gbà Sakramenti na mimọ́; (nitori igba na li awa njẹ ẹran ara Kristi, ati ti awa sì nmu èjẹ rẹ̀ nipa ẹmmí; nigba na ni awa mba Kristi gbé, ati ti Kristi sì mba wa gbé; awa di ọkan pẹlu Kristi, ati Kristi sì di ọkan pẹlu wa;) bẹ̃ li ewu na sì tobi, bi awa ba gbà eyi na li alaiyẹ. Nitori igba na li awa jẹbi Ara on Ẹjẹ Kristi Olugbala wa; awa njẹ awa sì nmu ẹbi ara wa, awa kò rò Ara ti Oluwa; awa ntinabọ ibinu Ọlọrun si ara wa lori; awa ntọ́ ọ lati fi onirũru arun ati ikú ba wa ja. Nitorina arakọnri ẹ ba ara nyin wijọ, ki a ma ti ọwọ́ Ọlọrun ba nyin wijọ; ẹnyin ronupiwada nitõtọ nitori èṣẹ nyin ti o ti kọja; ẹnyin ni igbagbọ́ ãye ati igbagbọ́ ti o duro ṣinṣin nipa Kristi Olugbala wa; ẹnyin ṣe

Digitized by Google

atun-hù rere ìwa, ki ẹnyin ki o sì wà ni ifẹni afẹtan si gbogbo enia; bẽli ẹnyin o sì ṣe alabapin ọ̀rọ̀ ijinlẹ̀ mimọ́ wọnyi bi o ti yẹ. Ati bori ohun gbogbo ki ẹnyin ki o ma fi iparamọ ati tọkkàn-tọkkàn dupẹ gidigidi fu Ọlọrun, Babba, Ọmmọ, ati fu Ẹmmí Mimọ́, nitori idande araiye nipa ikú ati ìya Kristi Olugbala wa, ẹniti ṣe Ọlọrun ati enia; ẹniti o rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ titi o fi de ikú ori Agbelebu, fu awa ọ̀tọ̀ṣi ẹlẹṣẹ, awa ti o wà li ọ̀kunkun ati ninu ojiji ikú; ki o le sọ wa di ọmmọ Ọlọrun, ati ki o le gbé wa soke si ìye ti kò nipẹkun. Ati nitori ki awa ki o le ma ranti ifẹ nla ti Babba wa, Jesu Kristi Olugbala wa nikanṣoṣo nigba-gbogbo, ti o kú bayi fu wa, ati ore alniye ti o fi ẹjẹ rẹ̀ iyebiye ti o ta silẹ gbà fu wa; o sì ti da, o sì ti làna ọ̀rọ̀ ijinlẹ̀ mimọ́ silẹ, bi igbọwọ-ẹri ifẹ rẹ̀, ati fu iranti ikú rẹ̀ titi lai, fu itunu nla wa ti kò li opin. Nitorina fu u, pẹlu Babba ati Ẹmmí Mimọ́ (bi iṣẹ́ wa ti jasi) ki a ma fi ọpẹ́ fu titi lai; ki a ma fi ara wa le ifẹ ati ìwu mimọ́ rẹ̀ lọwọ́ patapata, ki awa ki o sì ma rò lati ma sìn i nitõtọ ni mimọ́ ìwa ati li ododo li ọjọ́ aiye wa gbogbo. *Amin.*

Nigbana li Alufa o wi fu wọn pe.

ẸNYIN ti o ronupiwada ẹṣẹ nyin nitõtọ ati tọkkàn-tọkkàn, ti ẹnyin sì wà ninu ifẹ ati ifẹni si ẹnikeji nyin, ti ẹnyin sì nfẹ lati ma rìn ni ìwa titun, lati ma tọ̀pa ofin Ọlọrun, ti ẹnyin sì nrìn lati isisiyi lọ li ọ̀na mimọ́ rẹ̀; Ẹ fi igbagbọ́ sumọ́ ihin, ki ẹnyin ki o sì gbà Sakramenti mimọ́ yi fu itunu nyin; ki ẹnyin ki o sì ma fi iparamọ ṣe ijẹwọ fu Ọlọrun Olodumare, ki ẹnyin ki o sì fi ọkkàn tutù kunlẹ li ẽkun nyin.

Digitized by Google

IDAPỌ MIMỌ́.

IJẸWỌ.

OLỌRUN Olodumare, Babba Jesu Kristi Oluwa wa, Ẹlẹda ohun gbogbo, Onidajọ́ gbogbo awọn enia; Awa jẹwọ, awa sì npohunrere ẹkún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀ṣẹ ti awa ti nda, ati ìwabuburu wa, Ti awa ti nhù nigba-kūgba, Li ọkkàn, li ọ̀rọ, ati ni ìwa hihù, si Ọlá-nla ìwa mimọ́ rẹ, Awa ntọ́ ibinu ati irunu rẹ ti o tọ́ julọ si ara wa. Tọkkàn-tọkkàn li awa ronupiwada, Awa sì nkãnu iṣiṣe wa wọnyi lati inu wá; Ẹdun ni iranti wọn dà fu wa; Ẹrù wọn kò ṣe gbé. Ṣãnu fu wa, Ṣãnu fu wa, Babba alãnu julọ; nitori Jesu Kristi Ọmmọ rẹ Oluwa wa, Dari gbogbo eyi ti o ti kọja jì wa; Ki iwọ ki o sì fifuni lai lẹhin eyiyi, ki awa ki o le ma sìn, ki a le ma wù ọ, Li ọ̀tún ìwa, Fu ọlá on ogo Orukọ rẹ; Nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

IFIJI.

OLỌRUN Olodumare, Babba wa ti mbẹ li ọrun, ẹniti o ti inu ãnu rẹ̀ nla ṣe ileri idariji ẹ̀ṣẹ̀ fu gbogbo awọn ti o tinu ronupiwada, ati ti nwọn sì fi igbagbọ́ otitọ yipada si i; Ki o ṣãnu fu nyin; ki o dariji nyin, ki o gbà nyin kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀ nyin gbogbo; ki o mu ẹsẹ nyin duro ki o sì mu nyin lara le ninu ore gbogbo; ki o sì mu nyin de inu ìye ti kò nipẹkun; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Nigbana li Alufa o wipe.

Ẹ gbọ́ ọrọ itunu ti Kristi Olugbala wa sọ fu gbogbo awọn ti o yipada si i nitõtọ.

GBOGBO ẹniti o ba nṣe ipọnju ti a sì ndi ẹrù wuwo le lori ki o tọ̀ mi wá, emi o sì tù nyin lara. *Mat.* 11. 28.

Digitized by Google

Ọlọrun fẹ araiye tobẹ gẹ, ti o fi Ọmmọ bíbi rẹ nikanṣoṣo funi, nitori idi eyi pe, ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ kì yio ṣegbé ṣugbọn yio ni ìye ti kò nipẹkun. *Joh.* 3. 16.

Ẹ gbọ́ bi Paulu ti wi pẹlu.

Eyiyi li ọ̀rọ otitọ, o sì yẹ lati gbà si ọwọ́ enia gbogbo, pe Kristi Jesu wá si aiye lati gbà ẹlẹṣẹ là. 1 *Tim.* 1. 15.

Ẹ gbọ́ bi Johanu ti wi pẹlu.

Bi ẹnikẹni ba ṣẹ̀, awa ni Alagbawi lọdọ Babba, Jesu Kristi olododo; on sì li ètutu fu ẹ̀ṣẹ wa. 1 *Joh.* 2. 1.

¶ *Lẹhin eyi ni Alufa o ma wipe.*

Alufa. Ẹ gbé àiya nyin soke.

Idahun. Awa gbé wọn soke si Oluwa.

Alufa. Ẹ jẹ ki awa ki o dupẹ fu Oluwa Ọlọrun wa.

Idahun. O yẹ, o sì tọ́ bẹ̃ lati ma ṣe.

¶ *Nigbana li Alufa yio yipada si Tabeli Oluwa, o sì wipe.*

OYẸ jọ̀jọ, o tọ́, iṣẹ́ ìsin wa sì ni, ni igba gbogbo, ati ni ibi gbogbo, ki awa ki o ma dupẹ fu ọ, Oluwa, Babba Mimọ́,* Olodumare, aiye-raiye Ọlọrun.

---

* Ọ̀rọ nwọnyi, *Babba Mimọ́*, ki a fò li ọjọ Ọlọrun ti Mẹtalọkan.

Digitized by Google

¶ *Nihinyi ni ki Alufa ki o gbà adura na ti a yàn silẹ fu ọjọ ọtọ, tabi eyi.*

NITORI na pẹlu awọn Angeli, ati awọn Olori Angeli, ati pẹlu gbogbo awọn ẹgbẹ ọrun, awa nyìn, awa sì ngbé Orukọ rẹ ti o li ogo ga; titi lai, awa sì nyìn ọ pe, Mimọ́, mimọ́, mimọ́, Oluwa Ọlọrun awọn ọmmọ ogun, ọrun on aiye sì kún fu ogo rẹ: Ogo ni fu iwọ, Oluwa Ọga-ogo julọ. *Amin.*

ADURA FU ỌJỌ ỌTỌ.

¶ *Li* Ọjọ ti Ibí Kristi, *ati ni ijọ meje lẹhin rẹ.*

NITORI ti iwọ fi Jesu Kristi Ọmmọ rẹ nikanṣoṣo funi lati di bíbi li akokò yi fu wa; nipa iṣẹ́ Ẹmmí Mimọ́ rẹ, ẹniti a da li ọkọnri iyọkọnri, li ara Maria Wundia iya rẹ; ati li alni abawọn ẹṣẹ, lati sọ wa di mimọ́ kuro ninu ẹṣẹ gbogbo. Nitorina pẹlu awọn Angeli, &c.

¶ *Li* Ọjọ ti Ajinde, *ati ni ijọ meje lẹhin rẹ.*

ṢUGBỌN ju gbogbo rẹ lọ iṣẹ́ wa ni lati ma yìn ọ nitori Ajinde Jesu Kristi Ọmmọ rẹ Oluwa wa ti o li ogo: nitori on tikararẹ li Ọdọ agutan Irekọja, ti a fi fu wa, ti o sì ti kó ẹṣẹ aiye lọ; nipa ikú rẹ ẹniti o sì ti pa ikú run, ati nipa ajinde rẹ tún pada di ãye o sì tún mu ìye ti kò nipẹkun pada wa fu wa. Nitori na pẹlu awọn Angeli, &c.

¶ *Li* Ọjọ ti Igòke re ọrun, *ati ni ijọ meje lẹhin rẹ.*

NITORI Ọmmọ rẹ olufẹ ọwọn julọ Jesu Kristi Oluwa wa; lẹhin Ajinde rẹ ti o li

Digitized by Google

ogo julọ, ẹniti o fi ara hàn fu gbogbo awọn Aposteli rẹ̀ nigbangba, li oju wọn ti o sì lọ soke ọrun lati lọ pèse ipò fu wa; pe nibiti on ba gbé wà, nibẹ̀ li awa o gòke lọ pẹlu, ti awa o sì jọba pẹlu rẹ̀ li ogo. Nitori na pẹlu awọn Angeli, &c.

¶ *Li* Ọjọ́ Ọlọ́RUN Funfun *ati ni ijọ́ mẹ́fa lẹ́hin rẹ̀.*

NITORI Jesu Kristi Oluwa wa; gẹgẹ nipa ileri rẹ̀ ti o ṣe otitọ julọ, Ẹmmí Mimọ́ ẹ̀kalẹ lati ọrun wá bi akokò yi li ojijì pẹlu iró nla, bi ẹnipe afẹfẹ nla ni, li aworan ahọn iná, o mbà le awọn Aposteli, lati kọ́ wọn, ati lati fi ẹsẹ wọn le ọ̀na otitọ gbogbo; o nfu wọn li ẹ̀bun lati fọ onirũru èdè, ati igboiya pẹlu igbona itara, lati ma wasu Ihin-rere fu gbogbo orilẹ̀ èdè nigba-gbogbo; nipa eyi ti a ti mu wa jade kuro ninu òkunkun ati ninu ìṣina si imọlẹ gbangba ati si ìmọ otitọ rẹ̀, ati ti Ọmmọ rẹ̀ Jesu Kristi. Nitori na pẹlu awọn Angeli, &c.

¶ *Li* Ọjọ́ Ọlọrun ti Mẹ́talọkan *nikan.*

ẸNITI ṣe Ọlọrun kan, Oluwa kan; kì iṣe kìki Ẹni ọkan, ṣugbọn Ẹni mẹta li Ohun ìwa kan. Nitori eyi ti awa gbagbọ́ ni ti ogo ti Babba, on na li awa gbagbọ́ ni ti Ọmmọ, ati ni ti Ẹmmí Mimọ́, li alyatọ ati li altara wọn yọ. Nitori na pẹlu awọn Angeli, &c.

¶ *Nigbana li Alufa o kunlẹ̀ lẹba Tabeli Oluwa, ati li orukọ awọn ẹniti nwá si Idapọ mimọ́, o gbà Adura yi pẹ.*

OLUWA alãnu, awa kò làkaka lati wá si Tabeli rẹ yi, ni igbẹkẹle ododo ara wa,

Digitized by Google

bikoṣe li ọpọlọpọ ãnu rẹ nla. Awa kò yẹ tobẹ̃ lati ṣà ẹrún akara labbẹ Tabeli rẹ. Ṣugbọn iwọ li Oluwa na, ìwa ẹniti ṣe ati ṣãnu nigbagbogbo: Nitori na fifu wa, Oluwa olore ọfẹ, lati jẹ ẹran ara ti Jesu Kristi Ọmmọ rẹ ọwọn bẹ̃, ati lati mu ẹ̀jẹ rẹ̀, ki a le sọ ara ẹ̀ṣẹ wa di mimọ́ nipa ara rẹ̀, ati ki a le wẹ̀ ọkkàn wa nù nipa ẹ̀jẹ rẹ̀ iyebiye, ki awa ki o sì ma ba a gbé ninu rẹ̀ titi lai, ki on ki o sì ma ba wa gbé ninu wa. *Amin.*

¶ *Nigbati Alufa nduro niwaju Tabeli, ti o sì tò Akara ati Ọti wain lẹṣẹṣẹ tan, yio gbà Adura Isọ-di-mimọ́ pe.*

OLỌRUN Olodumare, Babba wa ti mbẹ li ọrun, iwọ ẹniti o ti inu iyọnu ãnu rẹ fi Jesu Kristi Ọmmọ rẹ̀ kanṣoṣo funi lati jìya ikú lori agbelebu, fu idande wa; (nipa ẹbọ kan ti o fi ara rẹ̀ ru lẹ̃kan) ẹniti o ru ẹbọ itẹnilọrùn, ẹbọ arukún, ati aruda, ẹbọ ti o to, fu ẹ̀ṣẹ ti gbogbo aiye; o sì da a silẹ, ati ninu Ihin-rere rẹ̀ mimọ́ o fi ohun silẹ fu wa lati ma ṣe e titi, iranti ti kò li opin ti ikú rẹ̀ iyebiye, titi yio sì fi tun pada wá; Ẹbọ́ ti wa, Babba alãnu julọ, gidigidi li awa nfi irẹlẹ ohùn bẹ̀bẹ lọdọ rẹ; ki iwọ ki o sì fifuni, ki awa ti ngbà akara ati ọti wain ẹda rẹ wọnyi, gẹgẹ bi idasilẹ mimọ́ ti Ọmmọ rẹ Jesu Kristi Olugbala wa, ni iranti ikú on ìya rẹ̀, ki awa ki o le ṣe alabapin ti Ara on Ẹ̀jẹ rẹ̀ ti o ni ibukún julọ: li oru ijọ na ti a ṣofofo rẹ̀, ẹniti o* mu Akara; nigbati o sì ti dupẹ,† o bu u, o sì fifu awọn ọmmọ ẹhin

---

* Nibi li Alufa o gbé awo li ọwọ́ rẹ̀:

† Nibi li o bu Akara:

Digitized by Google

rẹ, o nwipe, Gbà, jẹ,* eyiyi li Ara mi ti a fifu nyin: Ẹ ma ṣe eyi ni iranti mi. Bẹ̀ gẹgẹ lẹhin onjẹ o † gbé Ago; nigbati o sì ti dupẹ, o fifu wọn, o nwipe, Gbogbo nyin ẹ mu ninu eyi; nitori eyi ‡ li Ẹjẹ mi ti Majẹmu Titun, ti a ta silẹ fu nyin ati fu ẹni pupọ̀ nitori imukuro ẹ̀ṣẹ̀: Nigba-kũgba ti ẹnyin ba nmu u, ẹ ma ṣe eyi ni iranti mi. *Amin.*

¶ *Ipinfuni Akara.*

ARA Jesu Kristi Oluwa wa, ti a fifu ọ, ki o pa ara ati ọkkàn rẹ mọ́ titi ìye ti kò nipẹkun. Gbà ki iwọ ki o mu yi jẹ, ni iranti pe Kristi kú fu ọ, ki iwọ ki o sì ma fi igbagbọ́ li ọkkàn rẹ jẹun lara rẹ̀, pẹlu idupẹ.

¶ *Fi Ago funi.*

ẸJẸ Jesu Kristi Oluwa wa, ti a ta silẹ fu ọ, ki o pa ara ati ọkkàn rẹ mọ́ titi ìye ti kò nipẹkun. Gbà yi mu, ni iranti pe ẹ̀jẹ Kristi a ta silẹ fu ọ, ki iwọ ki o sì ma dupẹ.

¶ *Nigbana li Alufa o gbà Adura Oluwa, awọn enia wi lẹhin rẹ̀ pe.*

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọ̀wọ li orukọ rẹ. Ijọba rẹ de. Ifẹ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ojọ wa loni. Dari ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wa, Bi a ti ndari ẹ̀ṣẹ̀ jì awọn tì o ṣẹ̀ wa. Má fà wa sinu idẹwò;

---

* Nibi li o fi ọwọ́ rẹ le ori Akara gbogbo.

† Nibi li o gbé Ago li ọwọ́ rẹ:

‡ Nibi li o fi ọwọ́ rẹ le ori gbogbo ohun èlo, bi o ṣe Ago tabi Igo, ti o ni Ọti wain ninu fu isọ-di-mimọ́,

Digitized by Google

Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin. Nitori ijobba ni ti rẹ, agbara ni ti rẹ, ogo ni ti rẹ, lailai. Amin.

¶ *Lẹhin na o sì gbadura bayi.*

OLUWA ati Babba ọrun, awa awọn onipa-ramọ ọmmọ ọdọ rẹ nfẹ ore rẹ bi ti Babba patapata, ki iwọ ki o fi ãnu gbà ẹbọ iyìn ati ọpẹ́ wa yi; awa sì nfi iparamọ buru-buru bẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ lati fifuni, pe nipa itoye ati ikú ti Jesu Kristi Ọmmọ rẹ, ati nipa igbagbọ́ li ẹ̀jẹ̀ rẹ̀, awa ati gbogbo Ijọ awọn enia rẹ, ki a le ri imukuro ẹ̀ṣẹ̀ wa gbà, ati gbogbo ore omiran ti ṣe ti inu ìya rẹ̀. Ati nihinyi li awa fi awa tikara wa, ọkkàn wa, ati ara wa le ọ lọwọ́, Oluwa, lati ṣe ẹbọ ti o yẹ, ti o mọ́, ti o sì ṣe ẹbọ ãye si ọ; awa sì nfi iparamọ bẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, ki gbogbo awa, ti a ṣe alabapin ti Idapọ mimọ́ yi, ki a le fi ore-ọfẹ ati ibukún rẹ ọrun kún wa. Bi awa kò sì ti yẹ, nitori ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ wa, lati ṣe ẹbọ-kẹbọ si ọ, ṣugbọn awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o gbà iṣẹ́ ati ìsin wa yi; máṣe wọn itoye wa wò, bikoṣepe ki iwọ ki o dari ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wa, nitori Jesu Kristi Oluwa wa; nipa ọdọ ẹni, ati pẹlu ẹni, ni iṣọkan Ẹmmí Mimọ́, gbogbo ọlá ati ogo wa fu ọ, Babba Olodumare, aiye alàinipẹkun. *Amin.*

Tabi eyi.

OLODUMARE ati lai Ọlọrun alãye, tọkkàn-tọkkàn li awa fi ndupẹ lọdọ rẹ, nitori ti iwọ fiyẹ si i lati bọ́ awa ti o gbà ọ̀rọ̀ ijinlẹ mimọ́ wọnyi bi o ti yẹ, pẹlu onjẹ ẹmmí ti Ara on Ẹjẹ iyebiye ti Jesu Kristi Ọmmọ rẹ Olugbala wa; ti iwọ sì fi eyi-ni mu wa li ọkkàn le, niti oju-rere ati ore rẹ si wa; ati pe awa li ẹ̀ya ara tikara rẹ na ti o dàpọ̀ li ara ọ̀rọ̀ ijinlẹ

Digitized by Google

Ọmmọ rẹ, eyi-ni li ẹgbẹ gbogbo awọn onigbagbọ́ ti o ni ibukún; ati awọn pẹlu nipa ireti ti ṣe ijogún ijọbba rẹ ti kò nipẹkun, nipa itoye ti ikú ati ijiya iye-biye ti Ọmmọ rẹ ọwọn. Gidigidi li awa sì nfi irẹlẹ ohùn bẹbẹ lọdọ rẹ, Babba ọrun, ki iwọ ki o fi ore-ọfẹ ràn wa lọwọ́ bẹ̃, ki awa ki o le duro titi ninu ẹgbẹ mimọ́ na, ki awa ki o sì ma ṣe irú iṣẹ́ rere bi iwọ ti pèse silẹ fu wa lati ma rìn ninu wọn; nitori Jesu Kristi Oluwa wa, fu ẹni, pẹlu iwọ ati Ẹmmí Mimọ́, ti gbogbo ọlá on ogo wà fu, aiye ainipẹkun. *Amin.*

Nigbana li a o wipe.

OGO ni fu Ọlọrun li oke ọrun, ati li aiye alafia, ifẹ́ inu rere si enia. Awa nyìn ọ, awa nfi ibukún fu ọ, awa nfi ori-balẹ fu ọ, awa nyìn ọ li ogo, awa ndupẹ fu ọ nitori ogo rẹ nla, Ọlọrun Oluwa, Ọbba ọrun, Ọlọrun Babba Olodumare.

Oluwa, Ọmmọ bíbi kanṣoṣo na Jesu Kristi; Ọlọrun Oluwa, Ọdọ agutan Ọlọrun, Ọmmọ ti Babba, ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ́ aiye lọ, ṣãnu fu wa. Iwọ ti o kó ẹ̀ṣẹ́ aiye lọ, ṣãnu fu wa. Iwọ ti o kó ẹ̀ṣẹ́ aiye lọ, gbà adura wa. Iwọ ti o joko li ọwọ́ ọtún Ọlọrun Babba, ṣãnu fu wa.

Nitori iwọ nikan ni mimọ́; iwọ nikan li Oluwa; iwọ nikan, Kristi, pẹlu Ẹmmí Mimọ́, li o ga julọ ninu ogo Ọlọrun Babba. *Amin.*

Ibukún.

KI alafia Ọlọrun, ti o jù imọran gbogbo lọ, ki o pa nyin li àiya on ọkkàn mọ́ ni imọran on ifẹ́ Ọlọrun, ati ti Jesu Kristi Ọmmọ

Digitized by Google

rẹ̀ Oluwa wa; ati ibukún Ọlọrun Olodumare, ti Babba, ti Ọmmọ, ati ti Ẹmmí Mimọ́, ki o wà ninu nyin, ki o sì ma ba nyin gbé nigbagbogbo. *Amin.*

Adura.

OLUWA, fi ãnu ràn wa lọwọ́, ninu ẹ̀bẹ ati adura wa wọnyi, ki iwọ ki o sì fà ọkkàn awọn ọmmọ ọdọ rẹ si atini igbala ti kò nipẹkun; ninu ayida ati alabapade aiye ikú yi, ki a le ma dãbobo wọn nipa iranlọwọ ore-ọfẹ rẹ ti o mura julọ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

OLUWA Olodumare, ati aiye-raiye Ọlọrun, fiyesini, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, lati fi ọna hàn, lati sọni di mimọ́, ati lati ṣe akoso, àiya ati ara wa, nipa ọna ati iṣẹ́ ofin rẹ; ati nipasẹ àbo rẹ ti o lagbara julọ, ati nihinyi ati lai, ki a le ma pa wa mọ́ li ara ati li ọkkàn; nitori Jesu Kristi Oluwa ati Olugbala wa. *Amin.*

OLỌRUN Olodumare, fifu wa awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ki gbogbo ọ̀rọ, ti awa fi ode etí wa gbọ́ loni, nipa ore-ọfẹ rẹ, ki a gbìn i si wa li àiya, ki nwọn ki o le ma so eso ìwa rere ninu wa, fu ọlá ati iyìn Orukọ rẹ, nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

OLUWA, fi ore-ọfẹ rẹ julọ, ṣaju wa ni gbogbo ṣiṣe wa, ki o sì ma fi iranlọwọ rẹ titi sún wa si iwaju; ni gbogbo iṣẹ́ wa ti a bẹ̀rẹ si, ti a nṣe lọ, ti a sì ṣe pari lọdọ rẹ, ki awa ki o le ma yìn Orukọ mimọ́ rẹ li ogo, ati nikẹhin nipa ãnu rẹ ki a le ni ìye ti kò nipẹkun; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

IDAPỌ MIMỌ́.

OLỌRUN Olodumare, olorisọn ọgbọ́n gbogbo, iwọ ẹniti o mọ̀ ipọnju wa ki awa ki o to ma bère, ati almoye wa ni ìbere; Awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o ṣãnu si allera wa; ati ohun wọn-ni, nitori alalyẹ wa ti awa kò gbọdọ tọrọ, ati nitori ifọju wa ti awa kò le bère, fiye si i lati fifu wa, nitori ẹyẹ Ọmmọ rẹ Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

OLỌRUN Olodumare, iwọ ẹniti o ti ṣe ileri lati gbọ́ ẹ̀bẹ awọn ti mbère li Orukọ Ọmmọ rẹ; Awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fi ãnu dẹ etí rẹ silẹ si awa ti ngbadura, ti a sì mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ nisisiyi; ki iwọ ki o sì fifuni, ohun wọn-ni, ti awa nfi igbagbọ́ bẹ̀bẹ gẹgẹ bi ifẹ́ rẹ, ki a le ri wọn gbà ni ijẹ, ti yio dẹni lara ipọnju wa, ati lati gbé ogo rẹ kalẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

IṢẸ́ TI BAPTISMU

TI AWỌN ỌMMỌ ỌWỌ.

¶ *Ni ijọ Ọlọrun ni ki Alufa ki o baptisi awọn ọmmọ ọwọ li oju ijọ awọn enia Ọlọrun, ki o sì bi pe.*

ATI baptisi, tabi a kò ti baptisi Ọmmọde yi?

¶ *Bi nwọn ba dahùn pe, A kò ti baptisi rẹ̀; Nigbana ni ki Alufa ki o ma wipe,*

ENYIN olufẹ ọwọn, bi a ti lóyun ti a sì bí gbogbo enia ninu ẹ̀ṣẹ; ti Kristi Olugbala wa, sì wipe, Kò si ẹniti o le wọle ijọba Ọlọrun, bikoṣepe a tún u da, ki a sì fi Omi ati Ẹ̀mí Mimọ́ tún u bí; Emi mbẹ̀ nyin lati ma kepè Ọlọrun Babba, nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa, ninu ore ãnu rẹ̀ pupọ̀, ki o le fi ohun ti *Ọmmọde yi* kò le fi ipa ti ẹda ni fu u; ki a le fi Omi ati Ẹ̀mí Mimọ́ baptisi rẹ̀, ki a sì le gbà *a* sinu Ijọ awọn enia mimọ́ Kristi, ki a sì le sọ ọ di ẹgbẹ ãye ti awọn enia na.

¶ *Nigba na li Alufa o wipe.*

Ẹ jẹ ki a gbadura.

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, iwọ ẹniti o ti inu ãnu rẹ nla gbà Noa ati awọn

Digitized by Google

arale rẹ̀ là ninu ọkọ̀ kuro ninu egbé nipa omi; ati ti o sì fi alafia mu awọn ọmmọ Israeli awọn enia rẹ̀ là Okun Pupa já, ti iwọ fi eyi-ni ṣapẹrẹ Baptismu mimọ́ rẹ̀; ati ti iwọ sì fi Baptismu ti Jesu Kristi Ọmmọ rẹ̀ olufẹ, li odò Jordan, ṣọ Omi di mimọ́ lati wẹ̀ ẹ̀ṣẹ̀ nù nipa ọ̀rọ̀ ijinlẹ̀; Awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ̀, nitori ãnu rẹ̀ ti kò nipẹkun, ki iwọ ki o le fi ãnu wò *Ọmmọde yi;* wẹ̀ ẹ̀ nù, ki o sì fi Ẹmmí Mimọ́ ṣọ ọ di mimọ́; nitori pe bi a ti yọ ọ kuro ninu ibinu rẹ̀, ki a sì le gbà *a* sinu ọkọ̀ ti Ijọ awọn enia Kristi; ti *on* sì nduro gangan ni igbagbọ́, ti on nyọ̀ ni ireti, ti *on* sì nfi gbongbo mulẹ̀ ni ifẹni, ki on ki o le là riru omi iyọnu aiye yi já tobẹ̃, nigbẹhin ki on ki o le de ilẹ̀ ìye ti kò nipẹkun, nibẹ̀ ki on ki o ma ba iwọ jọbba aiye alànipẹkun; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

OLODUMARE ati lai Ọlọrun alãye, alafẹhinti gbogbo awọn ẹniti ṣe alaìni, alãbo gbogbo awọn ẹniti o sá-di ọ, ẹmmí awọn ẹniti o gbagbọ́, ati ajinde awọn okú; Awa npè orukọ rẹ̀ nitori *Ọmmọde yi,* bi on ti mbọwá si Baptismu mimọ́ rẹ̀, ki on ki o le ri ifiji ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ gbà nipa atunda ẹmmí. Gbà *a,* Oluwa, bi iwọ ti ti ẹnu Ọmmọ rẹ̀ olufẹ ṣe ileri, pe, Bère, ẹnyin o sì ri gbà; wá kiri, ẹnyin o sì ri; kànkun, a o sì ṣí i silẹ̀ fu nyin: Bẹ̃ni ki iwọ ki o fifu awa ti mbère nisisiyi; jẹ̀ ki awa ti nwá kiri, ki a ri; ṣí ilẹkun silẹ̀ fu awa ti nkànkun; ki *Ọmmọde* yi ki o le jẹ̀ ibukún ti ìwẹnu rẹ̀ ọrun ti kò nipẹkun, ki on ki o sì le de ijọbba rẹ̀ ti kò nipẹkun, ti iwọ ti ṣe ileri nipa Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

¶ *Nigbana li awọn enia o dide duro, Alufa o sì wipe.*

Ẹ gbọ́ ỳrọ Ihin-rere, ti ati ọwọ́ Marku kọ, ni Kapu ẹkẹwa ni ferse ẹkẹtala.

NWỌN gbé awọn ọmmọ ọwọ tọ Kristi wá, ki o le fi ọwọ́ rẹ tọ́ wọn; awọn ọmmọ ẹhin rẹ sì ba awọn ti o gbé wọn wá wi. Ṣugbọn nigbati Jesu ri i, inu rẹ̀ bajẹ̀ pọ̀ju, o sì wi fu wọn pe, Ẹ jẹ ki awọn ọmmọ ọwọ ki o ma wá sọdọ mi, ẹ má sì ṣe da wọn lẹkun: nitori ti irú wọn ni ijọba Ọlọrun. Lõtọ ni mo wi fu nyin, Ẹnikẹni ti kò ba gbà ijọba Ọlọrun bi ọmmọ kekere, kì yio le wọ inu rẹ̀. Ó sì gbé wọn soke li apa rẹ̀, o fi ọwọ́ rẹ̀ le wọn, o sì sùre fu wọn.

¶ *Lẹhin eyi Alufa o gbà enia niyanju bayi pe.*

OLUFẸ, ẹnyin gbọ́ ỳrọ Kristi Olugbala wa ninu Ihin-rere yi, bi o ti fi aṣẹ funi lati ma mu awọn ọmmọ tọ́ on wá; bi o sì ti ba awọn ti iba ma da wọn pada kuro lọdọ rẹ̀ wi; bi o sì ti gbà gbogbo enia niyanju lati ma tọ̀pa ìwa allẹṣẹ wọn. Ẹnyin kiye si i bi o ti fi iṣe rẹ̀ ti o hàn fi ifẹ́ inu rere rẹ̀ hàn fu wọn; nitori ti o gbé wọn mọra li apa rẹ̀, o fi ọwọ́ rẹ̀ le wọn, o sì sùre fu wọn. Nitori na ki ẹnyin ki o má ṣiye-meji, ṣugbọn ki ẹnyin ki o gbagbọ́ jọjọ, pe on yio sì fi inu rere gbà *Ọmmọde yi* bẽ gẹgẹ; yio sì fi apa ãnu rẹ̀ gbé *e* mọra; yio sì fu *u* ni ibukún ìye ti kò ni ipẹkun, yio sì sọ ọ di alabapin ni ijọba rẹ̀ ti kò nipẹkun. Njẹ nitori na bi a ti yi wa li ọkkàn pada tobẽ nipa ifẹ́ inu rere ti Babba wa ti mbẹ li ọrun si *Ọmmọde yi*, ti a ti sọ lati ẹnu Jesu Kristi Ọmmọ rẹ̀ wá; ti a kò sì kọnu

Digitized by Google

ohun kan pe, o fi inu rere gbà iṣẹ́ ifẹ́ni ti awa yi, ni ti a mu *Ọmmọde yi* wá si Baptismu mimọ́ rẹ̀; ẹ jẹ ki a fi igbagbó ati tọkkàn-tọkkàn dupẹ fu u, ki a sì ma wipe,

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, Babba wa ti mbẹ li ọrun, awa nfi iparamọ dupẹ lọdọ rẹ, nitori ti iwọ fiyesi ni lati pè wa si ìmọ ore-ọfẹ rẹ, ati si igbagbọ́ rẹ: Sọ ìmọ yi di pupọ̀, ki iwọ ki o sì ma fi igbagbọ́ yi gunlẹ ninu wa siwaju: Fi Ẹmmí Mimọ́ rẹ fu *Ọmmọde yi*, ki a le sọ ọ di atunbi, ki a sì le sọ ọ di ijogún igbala ti kò nipẹkun; nipa Jesu Kristi Oluwa wa, ẹniti o wà ti o sì njọba pẹlu iwọ ati pẹlu Ẹmmí Mimọ́, nisisiyi ati lailai. *Amin.*

Nigbana li Alufa o wi fu awọn Onigbọwọ bayi pe.

OLUFẸ ọwọn, ẹnyin mu *Ọmmọde yi* wá ihinyi lati baptisi *rẹ̀*, ẹnyin ti gbadura ki Jesu Kristi Oluwa wa ki o le fiyesi i lati gbà a, lati da *a* nide kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, lati fi Ẹmmí Mimọ́ sọ ọ di mimọ́, lati fi ijọba ọrun, ati ìye ti kò nipẹkun fu u. Ẹnyin sì ti gbọ́ pẹlu, pe Jesu Kristi Oluwa wa ti ṣe ileri ninu Ihinrere rẹ̀, lati fi ohun gbogbo ti ẹnyin ti gbadura lọwọ́ rẹ̀ fu nyin, ileri na ti on, nipa ti rẹ̀, yio sì mu u ṣẹ jù bẹ̃ lọ.

Njẹ nitori na, lẹhin ileri yi ti Kristi ti ṣe, ki *Ọmmọde yi* ẹ̀wẹ nitõtọ nipa ti *rẹ̀*, ki o ti ọdọ ẹnyin onigbọwọ *rẹ̀* ṣe ileri, (titi *yio* fi dàgba tobẹ̃ lati gbà a fu ara *rẹ̀*,) pe *on* o kọ̀ ẹ̀ṣu ati gbogbo iṣẹ́ rẹ̀ silẹ, ati pe *on* o sì ma gbà Ọrọ mimọ́ Ọlọrun gbọ́ nigba-gbogbo, ati pe *on* o sì ma fi igbọran pa ofin rẹ̀ mọ́.

Digitized by Google

Nję mo bère.

Alufa. Li orukọ *Ọmmọde yi*, iwọ kọ èṣu ati gbogbo iṣẹ rẹ̀ silẹ, afẹ asan ati ogo ti aiye, pẹlu ojukòkoro ifẹ rẹ̀ gbogbo, ati ifẹkufẹ ti ṣe ti ara, tobẹ̃ ti iwọ kì yio ma tọ wọn lẹhin, bẽni nwọn kì yio ma ṣe amọna rẹ?

Idahun. Mo kọ gbogbo wọn silẹ.

Alufa. Iwọ gbà Ọlọrun Babba Olodumare gbọ́, Ẹlẹda ọrun on aiye?

Iwọ gbà Jesu Kristi gbọ́ Ọmmọ bíbi rẹ nikanṣoṣo Oluwa wa? ati pe nipa Ẹmmí Mímọ́ li ati lóyun rẹ̀; a bí i ninu Maria Wundia; o jìya lọwọ́ Pontiu Pilatu, a kàn a mọ́ agbelebu, o kú, a sì sin i; o ṣọkalẹ rè ipò okú, ati pẹlu pe ni ijọ ẹkẹta o tún jinde; o rè oke ọrun, o sì joko li ọwọ́ ọtún Ọlọrun Babba Olodumare; ati pe nibẹ̀ ni yio gbé ti tún pada wá li opin aiye, lati ba ãye on okú wijọ?

Iwọ sì gbà Ẹmmí Mímọ́ gbọ́; Ijọ mímọ́ ti awọn enia Ọlọrun; Idapọ ti awọn Enia mímọ́; Idariji ẹṣẹ; Ajinde ara; ati lye ti kò nipẹkun lẹhin ikú?

Idahun. Gbogbo eyi ni mo gbagbọ́ tọkkàntọkkàn.

Alufa. Iwọ ha fẹ ki a baptisi rẹ ninu igbagbọ́ yi?

Idahun. Ifẹ inu mi ni.

Alufa. Iwọ o ha ma fi igbagbọ́ pa ifẹ ati ofin mímọ́ Ọlọrun mọ́, ki iwọ ki o sì ma rìn ninu wọn li ọjọ aiye rẹ gbogbo?

Idahun. Emi o pa a mọ́.

¶ *Nigbana li Alufa o wipe.*

OLỌRUN alãnu, fifuni ki a le sin ogbologbo Adamu ti ara *Ọmmọde yi* tobẹ̃, ki ọkọnri titun ni ki o hù soke ninu *rẹ̀*. *Amin.*

Digitized by Google

Fifuni, ki gbogbo ifẹkufẹ ara ki o kú ninu *rẹ* ati ki ohun gbogbo ti ṣe ti Ẹmmí ki o yè, ki o sì ma dàgba ninu rẹ. *Amin.*

Fifuni, ki on ki o le ni ipa ati agbara, lati ṣẹgun, ati lati bori èṣu, ati aiye, ati ara. *Amin.*

Fifuni, ki ẹnikẹni ti a fi oyè ati iṣẹ́ alufa wa yà si iwọ, ki a le fi ìwa átọrun-wa wọ́ wọn, ki a sì le san a fu wọn titi lai, nipa ãnu rẹ, Oluwa Ọlọrun olubukún, ẹniti o wà, ti o sì jọba ohun gbogbo, aiye ti kò nipẹkun. *Amin.*

OLODUMARE, ati lai Ọlọrun alãye, ẹniti Ọmmọ rẹ̀ Jesu Kristi olufẹ ọwọn julọ, nitori idariji èṣẹ wa, ti o ta omi on èjẹ lati ìha rẹ iyebiye jade; ti o sì fi aṣẹ fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ pe, ki nwọn ki o lọ kọ́ orilẹ ède gbogbo, ki nwọn ki o sì baptisi wọn Li Orukọ ti Babba, ati ni ti Ọmmọ, ati ni ti Ẹmmí Mimọ́; Juba, adura awọn enia rẹ, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ; sọ Omi yi di mimọ́ ni ìwẹnù èṣẹ nipa òrọ ijinlẹ; ki iwọ ki o sì fifuni ki *Ọmmọde yi,* ti a o baptisi ninu rẹ̀ nisisiyi ki on ki o le ri ẹkún ore-ọfẹ rẹ, ki on ki o sì ma wà ninu iye ti awọn onigbagbọ́, ati ti awọn ayanfẹ ọmmọ rẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

¶ *Nigbana li Alufa o gbé Ọmmọde na soke li apa rẹ o sì wi fu awọn Onigbọwọ pe,*

Sọ Ọmmọde yi li orukọ.

N. Mo baptisi rẹ Li Orukọ ti Babba, ati ni ti Ọmmọ, ati ni Ẹmmí Mimọ́. Amin.

Digitized by Google

¶ *Nigbana li Alufa o wipe.*

AWA gbà *Ọmmọde yi* sinu ijọ agbo Kristi,* awa sì sà a li àmi Agbelebu, apẹrẹ pe nikẹhin kì yio tiju lati jẹwọ igbagbọ́ Kristi ti a kàn mọ́ agbelebu, ati lati ba èṣẹ, aiye, ati èṣu jà bi ọkọnri labbẹ ọpágun rẹ̀; ki o sì duro bi ọmmọ ogun Kristi nitõtọ, ati bi ọmmọ ọdọ rẹ̀ titi opin ẹmmí rẹ̀ li aiye yi. Amin.

¶ *Nigbana li Alufa o wipe.*

KI ẹnyin ki o wò o nisisiyi, arakọnri olufẹ ọwọn, pe *Ọmmọde yi* di atunda, a sì lọ́ ọ sinu ara ti Ijọ awọn enia Kristi, ẹ jẹ ki awa ki o dupẹ fu Ọlọrun Olodumare nitori ore wọnyi, ki a sì fi ọkkàn kan gbadura sọdọ rẹ̀, ki *Ọmmọde yi* ki o le ma rìn ọjọ ẹmmí rẹ̀ iyokù gẹgẹ bi ipilẹṣẹ yi.

¶ *Gbogbo enia nkunlẹ a o gbà Adura Oluwa pe.*

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọ̀wọ li orukọ rẹ. Ijọbba rẹ de. Ifẹ́ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ojọ wa loni. Dari èṣẹ wa jì wa, Bi a ti ndari èṣẹ jì awọn ti o ṣẹ̀ wa. Má fà wa sinu idẹwò; Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin. Amin.

¶ *Nigbana li Alufa o wipe.*

TỌKKÀN-TỌKKÀN li awa fi ndupẹ lọwọ́ rẹ, Babba alãnu julọ, nitori ti o wù ọ lati fi Ẹmmí Mimọ́ rẹ tún *Ọmmọde yi* da, lati gbà a

* Nihinyi ni ki Alufa ki o sàmi Agbelebu si ọmmọ ni iwaju.

Digitized by Google

ṣe ọmmọ ara rẹ nipa isọdọmmọ, ati lati dà a pọ̀ mọ́ inu Ijọ awọn enia mimọ́ rẹ. Awa sì nfi irẹlẹ ohùn tọrọ lọdọ rẹ lati fifuni pe, bi o ti di okú si èṣẹ, ti o sì di ãye si ododo, ati pe bi a sì ti sin *i* pẹlu Kristi ni ikú rẹ̀, ki o le kàn ogbologbo ọkọnri mọ́ agbelebu, ati patapata ki o sì pa gbogbo ara èṣẹ run; ati pe bi a ti sọ ọ di onipin ni ikú Ọmmọ rẹ, ki o sì ṣe onipin li ajinde rẹ̀; bẽ nigbẹhin, pẹlu Ijọ awọn enia mimọ́ rẹ iyokù, ki *o* le ṣe ọkan ninu awọn ijogún ijọbba rẹ ti kò nipẹkun; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

¶ *Nigbana ni gbogbo enia dide duro, Alufa o wi iyanju yi fu awọn Onigbọwọ pe.*

NJẸ nisisiyi *Ọmmọde yi* ti ipa ọdọ ẹnyin awọn onigbọwọ rẹ̀ ṣe ileri lati kọ̀ èṣu ati gbogbo iṣẹ́ rẹ̀ silẹ, lati gbà Ọlọrun gbọ́, ati lati ma sìn i; ki ẹnyin ki o sì ma ranti pe, ipa ati iṣẹ́ ti nyin ni, lati fi oju to atikọ́ *Ọmmọde yi*, nigbati o ba to ohun ikọ́, ipinhun, ileri, ati ijẹwọ ironu, ti o ti ipa ọdọ nyin ṣe nihinyi. Ati itori ki o le mọ̀ nkan wọnyi daju, ki ẹnyin ki o ma pè e wá gbọ́ iwasu; pẹlu-pẹlu, ki ẹnyin ki o sì pèse ki o le kọ́ Igbagbọ́, Adura Oluwa, ati Ofin Mẹwẹwa, li ède ti a nfọ, ati ohun omiran gbogbo ti o yẹ fu Kristian lati mọ̀, ati lati gbagbọ́ fu ilera ọkkàn rẹ̀; ati ki a tọ́ *Ọmmọde yi* bi ìwa rere ọrun lati ma rìn ọjọ rẹ̀ ni ìwa-bi-Ọlọrun ati bi Kristian; ki a ma ranti nigba-gbogbo pe, Baptismu li ṣapẹrẹ ijẹwọ wa; eyi-ni ni, lati ma tọ̀pasẹ Jesu Kristi Olugbala wa, ati lati sọ wa dabi rẹ̀; pe bi o ti kú, ti o sì tún jinde fu wa, bẽli awa, ti a baptisi, iba sì ma di okú fu èṣẹ, ki a sì tún jinde sinu ododo; nigba-gbogbo ki awa ki o sì ma pọn gbogbo ifẹ́ buburu ati

Digitized by Google

ifẹkufẹ ọkkàn loju, ati ki awa ki o sì ma rìn lọ siwaju li ọjọ gbogbo ninu atọrun-wa ìwa gbogbo, ati ninu ìwa-bi-Ọlọrun.

¶ *Nigbana li Alufa o wipe.*

KI ẹnyin ki o ma fiye si i lati mu *Ọmmọde yi* tọ Bisọpu wá lati mu u li ọkkàn le, nigbakugba ti o ba kọ Igbagbọ, Adura Oluwa, ati Ofin Mẹwẹwa, li ède ti a nfọ, ati lati kọ ọ siwaju ninu Katekismu ti Ijọ awọn enia Ọlọrun ti a gbé kalẹ nitori eyi na.

Digitized by Google

IṢẸ́ TI BAPTISMỌ̀

TI AWỌN ÀGBA.

Awọn ẹniti o le dahùn fu ara wọn.

¶ *Ni ijọ Ọlọrun ni ki Alufa ki o baptisi awọn àgba na, ti a kọ́ ninu Ọrọ ati ìsin Ọlọrun, li oju ijọ awọn enia Ọlọrun, ki o sì bi pe.*

ATI baptisi, tabi a kò ti baptisi awọn Enia wọnyi?

¶ *Bi nwọn ba dahùn pe, A kò ti baptisi wọn; Nigbana ni ki Alufa ki o ma wipe.*

ENYIN olufẹ ọwọn, bi a ti lóyun, ti a sì bí gbogbo enia ninu ẹ̀ṣẹ, (awọn ti a sì bí nipa ti ara on li ara) awọn ti o sì wà nipa ti ara kò le wù Ọlọrun, nwọn wà ninu ẹ̀ṣẹ, nwọn sì nda ẹ̀ṣẹ atọwọwa pupọ̀; ti Kristi Olugbala wa sì wipe, Kò si ẹniti o le wọ̀le ijọbba Ọlọrun, bikoṣepe a tún u da, ki a sì fi Omi ati Ẹmmí Mimọ́ tún u bí; Emi mbẹ̀ nyin lati ma kepè Ọlọrun Babba, nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa, ninu ore ãnu rẹ̀ pupọ̀, ki o le fi ohun ti *awọn enia wọnyi* kò le fi ipa ti ẹda ni fu wọn; ki a le fi Omi ati Ẹmmí Mimọ́ baptisi *wọn*, ki a sì le gbà *wọn* sinu Ijọ awọn enia mimọ́ Kristi, ki a sì le sọ *wọn* di ẹgbẹ ãye ti awọn enia na.

Digitized by Google

BAPTISMU TI AWỌN ÀGBA.

¶ *Nigbana li Alufa o wipe.*

Ẹ jẹ ki a gbadura.

OLODUMARE ati aiye-raiye Ọlọrun, iwọ ẹniti o ti inu ãnu rẹ nla gbà Noa ati awọn arale rẹ là ninu ọkọ, kuro ninu egbé nipa omi; ati ti o sì fi alafia mu awọn ọmmọ Israeli awọn enia rẹ là Okun Pupa já, ti iwọ fi eyi-ni ṣapẹrẹ Baptismu mimọ́ rẹ; ati ti iwọ sì fi Baptismu ti Jesu Kristi Ọmmọ rẹ olufẹ, li odò Jordan, ṣọ Omi di mimọ́ lati wẹ ẹṣẹ nù nipa ọrọ ijinlẹ; Awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, nitori ãnu rẹ ti kò nipẹkun, ki iwọ ki o le fi ãnu wò *awọn ọmmọ* ọdọ rẹ *wọnyi;* wẹ *wọn* nù, ki o sì fi Ẹmmí Mimọ́ ṣọ *wọn* di mimọ́; nitori pe bi a ti yọ *wọn* kuro ninu ibinu rẹ, ki a sì le gbà *wọn* sinu ọkọ ti Ijọ awọn enia Kristi; ti *nwọn* sì nduro gangan ni igbagbọ́, ti *nwọn* nyọ ni ireti, ti nwọn sì nfi gbongbo mulẹ ni ifẹni, ki *nwọn* ki o le là riru omi iyọnu aiye yi já tobẹ, nigbẹhin ki *nwọn* ki o le de ilẹ lye ti kò nipẹkun, nibẹ ki nwọn ki o ma ba iwọ jọbba aiye alnipẹkun; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

OLODUMARE ati lai Ọlọrun alãye, alafẹhinti gbogbo awọn ẹniti ṣe alalni, alãbo gbogbo awọn ẹniti o sá-di ọ, ẹmmí awọn ẹniti o gbagbọ́, ati ajinde awọn okú; Awa mpè orukọ rẹ nitori *awọn enia wọnyi,* bi *nwọn* ti mbọwá si Baptismu mimọ́ rẹ, ki *nwọn* ki o le ri ifiji ẹṣẹ *wọn* gbà nipa atunda ẹmmí. Gbà *wọn,* Oluwa, bi iwọ ti ti ẹnu Ọmmọ rẹ olufẹ ṣe ileri, pe, Bère, ẹnyin o sì ri gbà; wá kiri, ẹnyin o sì ri; kànkun, a o sì ṣí i silẹ fu nyin; Bẹ̃ni ki iwọ ki o fifu awa ti mbère nisisiyi; jẹ ki awa ti nwá kiri, ki a ri; ṣí ilẹkun silẹ fu awa ti nkànkun; ki *awọn enia wọnyi* ki o le jẹ

Digitized by Google

ibukún ti iwẹnu rẹ ọrun ti kò nipẹkun, ki ǹwọn ki o sì le de ijọbba rẹ ti kò nipẹkun, ti iwọ ti ṣe ileri nipa Kristi Oluwa wa. *Amin.*

¶ *Nigbana li awọn enia o dide duro, Alufa o sì wipe.*

Ẹ gbọ́ ọrọ Ihin-rere, ti ati ọwọ́ Johanu kọ, ni Kapu ẹkẹta ni ferse ekini.

OKỌNRI kan wà ninu awọn Farisi, ti a npè ni Nikodemu, ijoye kan ninu awọn Ju. On na li o tọ Jesu wá li oru, o sì wi fu u pe, Rabi, awa mọ pe olukọni ti o ti ọdọ Ọlọrun wá ni iwọ ṣe; nitori ti kò si ẹni ti o le ṣe iṣẹ-iyanu wọnyi ti iwọ nṣe, bikoṣepe Ọlọrun wà pẹlu rẹ. Jesu dahùn o sì wi fu u pe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi fu ọ, Bikoṣepe a ba tún enia bí, on kì yio le ri ijọbba Ọlọrun. Nikodemu sì bi i pe, A o ti ṣe le tún enia bí, nigbati o di arugbo tan? o sì le tún wọ inu iya rẹ lọ nigba ekeji, ki a sì tún ọ bí? Jesu dahùn wipe, Lõtọ, lõtọ ni mo wi fu ọ, Bikoṣepe a tún enia bí nipa ti omi, ati nipa ti Ẹmmí, on kì yio le wọle ijọbba Ọlọrun. Eyi ti a bí nipa ti ara on li ara; eyi ti a sì bí nipa ti Ẹmmí on li ẹmmí. Ki ẹnu ki o má ṣe ya ọ, nitori eyi ti mo wi fu ọ pe, A kò le ṣe alaìtún nyin bí. Afẹfẹ nfẹ si ibi ti o gbé wù u, iwọ sì ngbọ́ irọ́ rẹ, ṣugbọn iwọ kò mọ ibi ti o gbé ti wá, ati ibi ti o gbé nlọ: gẹgẹ bẽ ni gbogbo awọn ẹniti a bí nipa ti Ẹmmí.

¶ *Lẹhin eyi Alufa o gbà enia niyanju bayi pe.*

OLUFẸ, ẹnyin gbọ́ ninu Ihin-rere yi, ọrọ Olugbala wa Kristi tikara rẹ, pe bi a kò ba bí enia nipa omi ati nipa Ẹmmí, on kì yio le wọle ijọbba Ọlọrun. Nipa eyi na ni ki ẹnyin

Digitized by Google

ki o ti kiye si i gidigidi bi a kò ti le ṣe alaìni Sakramenti yi, nibiti ọwọ́ ẹni ba gbé to o. Pẹlu-pẹlu nigbati o kù diẹ fu u lati lọ si oke ọrun (bi ati kọ ọ ni Kapu ikẹhin ti Ihin-rere Marku) o fi aṣẹ fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀, wipe, Ẹnyin lọ si gbogbo aiye, ki ẹ sì wasu Ihin-rere fu ẹda gbogbo. Ẹniti o ba gbagbọ́ ti a sì baptisi rẹ̀ yio là; ṣugbọn ẹniti kò ba gbagbọ́ yio ṣegbé. Eyiyi li o sì nfi ère ore nla ti awa nje nibẹ̀ hàn fu wa.

Nitori na ni Peteru Aposteli, nigba àtetekọ wasu rẹ̀ Ihin-rere, aiya gún ọ̀pọlọpọ enia, ti nwọn sì bi i, ati awọn Aposteli iyokù pe, Alagba ati arakọnri, kini ki awa ki o ṣe? o sì dahùn o sì wi fu wọn pe, Ẹ ronupiwada, ki a sì baptisi olukuluku nyin nitori imukuro ẹ̀ṣẹ, ẹnyin o sì ri ẹ̀bun Ẹmmí Mimọ́ gbà. Nitori ti ileri yi mbẹ fu nyin ati fu awọn ọmmọ nyin, ati fu gbogbo awọn ti o jìna, ati fu iye awọn ti Oluwa Ọlọrun wa yio pè. Ati ọ̀rọ pupọ̀ omiran li o fi gbà wọn niyanju, wipe, Ẹ gbà ara nyin là lọwọ́ iran arekereke yi. (Bi Aposteli na sì ti wi nibi omiran pe,) Nitori ti Baptismu pẹlu ngbà wa là nisisiyi, (kì iṣe ti imu ẽri ti ara kuro, bikoṣe ti idahùn ọkkàn rere sipa ti Ọlọrun,) nípa ajinde Jesu Kristi. Nitori na ki ọnu ki o má kọ nyin, ṣugbọn ki ẹnyin ki o gbagbọ́ tọkkàn-tọkkàn, pe, on yio fi inu rere gbà *awọn enia* isisiyi *wọnyi*, ti *nwọn* nronupiwada nitõtọ, ti *nwọn* sì nfi igbagbọ́ tọ̀ ọ wá; yio sì fi imukuro ẹ̀ṣẹ *wọn* fu *wọn*, yio sì fi Ẹmmí Mimọ́ fu *wọn;* ati pe on yio fi ibukún ìye ti kò nipẹkun fu wọn, o sì sọ *wọn* di alabapin ijọba rẹ̀ ti kò nipẹkun.

Njẹ nitori na bi a ti yi wa li *ọkkàn* pada tobẹ̃ nipa ifẹ́ inu rere ti Babba wa ti mbẹ li ọrun si *awọn enia wọnyi*, ti a ti sọ lati ẹnu Jesu Kristi

Digitized by Google

Ọmmọ rẹ̀ wá; ẹ jẹ ki a fi igbagbọ́ ati tọkkàn-tọkkàn dupẹ fu u, ki a sì ma wipe:

OLODUMARẸ ati aiye-raiye Ọlọrun, Babba wa ti mbẹ li ọrun, awa nfi iparamọ dupẹ lọdọ rẹ, nitori ti iwọ fiyesini lati pè wa si ìmọ ore-ọfẹ rẹ, ati si igbagbọ́ rẹ: Sọ ìmọ yi di pupọ̀, ki iwọ ki o sì ma fi igbagbọ́ yi gunlẹ ninu wa siwaju. Fi Ẹmmí mimọ́ rẹ fu *awọn enia wọnyi*, ki a le sọ wọn di atunbi, ki a sì le sọ wọn di ijogún igbala ti kò nipẹkun; nipa Jesu Kristi Oluwa wa, ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu iwọ ati pẹlu Ẹmmí Mimọ́, nisisiyi ati lailai. *Amin.*

Nigbana li Alufa o wi fu awọn ẹniti a o baptisi bayi pe.

OLUFẸ ọwọn, *ẹnyin* ẹniti o wá ihinyi ti *ẹnyin* nfẹ gbà Baptismu mimọ́, *ẹnyin* gbọ́ hi ijọ awọn enia Ọlọrun ti gbadura, ki Jesu Kristi Oluwa wa ki o le fiyesi i lati gbà *nyin*, lati bukún u fu *nyin*, lati da *nyin* nide kuro ninu èṣẹ *nyin*, lati fi ijọbba ọrun, ati ìye ti kò nipẹkun fu *nyin*. *Ẹnyin* sì ti gbọ́ pẹlu, pe Jesu Kristi Oluwa wa ti ṣe ileri ninu Ọrọ mimọ́ rẹ̀, lati fi ohun gbogbo ti awa ti gbadura lọwọ́ rẹ̀ fu wa; ileri na ti on, nipa ti rẹ̀, yio sì mu u ṣẹ jù bẹ̃ lọ.

Njẹ nitori na, lẹhin ileri yi ti Kristi ti ṣe, nitõtọ nipa ti *nyin*, *ẹnyin* kò sì gbọdọ má ṣe ileri li oju gbogbo awọn ẹlẽri *nyin* wọnyi ti *ẹnyin* yàn, ati li oju gbogbo ijọ awọn enia Ọlọrun yi, pe *ẹnyin* o kọ̀ èṣu ati gbogbo iṣẹ́ rẹ̀ silẹ, ati pe *ẹnyin* o sì ma gbà Ọrọ mimọ́ Ọlọrun gbọ́ nigba-gbogbo, ati pe *ẹnyin* o sì ma fi igboran pa ofin rẹ̀ mọ́.

Digitized by Google

Nję mo bère.

Alufa. Iwọ kọ̀ èṣu ati gbogbo iṣẹ́ rẹ̀ silẹ, afẹ asan ati ogo ti aiye, pẹlu ojukòkoro ifẹ́ rẹ̀ gbogbo, ati ifẹkufẹ ti ṣe ti ara, tobẹ̃ ti iwọ kì yio ma tọ̀ wọn lẹhin, bẽni nwọn kì yio ma ṣe amọ̀na rẹ?

Idahùn. Mo kọ̀ gbogbo wọn silẹ.

Alufa. Iwọ gbà Ọlọrun Babba Olodumare gbọ́, Ẹlẹda ọrun on aiye?

Iwọ gbà Jesu Kristi gbọ́ Ọmmọ bíbi rẹ̀ nikanṣoṣo Oluwa wa? ati pe nipa Ẹmmí Mimọ́ li ati lóyun rẹ̀; a bí i ninu Maria Wundia; o jìya lọwọ́ Pontiu Pilatu, a kàn a mọ́ agbelebu, o kú, a sì sin i; o ṣọkalẹ rè ipò okú, ati pẹlu pe ni ijọ ẹkẹta o tún jinde; o rè oke ọrun, o sì joko li ọwọ́ ọtún Ọlọrun Babba Olodumare; ati pe nibẹ̀ ni yio gbé ti tún pada wá li opin aiye, lati ba ãye on okú wijọ?

Iwọ sì gbà Ẹmmí Mimọ́ gbọ́; Ijọ mimọ́ ti awọn enia Ọlọrun; Idapọ ti awọn Enia mimọ́; Idariji ẹṣẹ; Ajinde ara; ati ìye ti kò nipẹkun lẹhin ikú?

Idahùn. Gbogbo eyi ni mo gbagbọ́ tọkkàntọkkàn.

Alufa. Iwọ ha fẹ ki a baptisi rẹ ninu igbagbọ́ yi?

Idahùn. Ifẹ́ inu mi ni.

Alufa. Iwọ o ha ma fi igbagbọ́ pa ifẹ́ ati ofin mimọ́ Ọlọrun mọ́, ki iwọ ki o sì ma rìn ninu wọn li ọjọ́ aiye rẹ̀ gbogbo?

Idahùn. Emi o pa a mọ́ nipa iranlọwọ́ Ọlọrun.

Nigbana li Alufa o wipe.

OLỌRUN alãnu, fifuni ki a le sin ogbologbo Adamu ti ara *awọn enia wọnyi* tobẽ̃, ki ọkọnri titun ni ki o hù soke ninu *wọn. Amin.*

Digitized by Google

Fifuni, ki gbogbo ifẹkufẹ ara ki o kú ninu *wọn*, ati ki ohun gbogbo ti ṣe ti Ẹmmí ki o yè, ki o sì ma dàgba ninu *wọn*. *Amin.*

Fifuni, ki *nwọn* ki o le ni ipa ati agbara, lati ṣegun, ati lati bori èṣu, ati aiye, ati ara. *Amin.*

Fifuni, ki ẹnikẹni ti a fi oyè ati iṣẹ́ alufa wa yà si iwọ, ki a le fi ìwa atọrun-wa wọ̀ wọn, ki a sì le san a fu wọn titi lai nipa ãnu rẹ, Oluwa, Ọlọrun olubukún, ẹniti o wà, ti o sì jọbba ohun gbogbo, aiye ti kò nipẹkun. *Amin.*

OLODUMARE, ati lai Ọlọrun alãye, ẹniti Ọmmọ rẹ̀ Jesu Kristi olufẹ ọwọn julọ, nitori idariji ẹṣẹ wa, ti o ta omi on ẹjẹ lati ìha rẹ̀ iyebiye jade; ti o sì fi aṣẹ fu awọn ọmmọ ẹhin rẹ̀ pe, ki nwọn ki o lọ kọ́ orilẹ ède gbogbo, ki nwọn ki o sì baptisi wọn Li Orukọ ti Babba, ati ni ti Ọmmọ, ati ni ti Ẹmmí Mimọ́; Juba, adura awọn enia rẹ, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ; sọ Omi yi di mimọ́ ni ìwẹnu ẹṣẹ nipa ọrọ ijinlẹ; ki iwọ ki o sì fifuni ki awọn enia wọnyi, ti a o baptisi ninu rẹ̀ nisisiyi ki nwọn ki o le ri ẹkún ore-ọfẹ rẹ, ki nwọn ki o sì ma wà ninu iye ti awọn onigbagbọ́, ati ti awọn ayanfẹ ọmmọ rẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Sọ eleyi li orukọ.

N. Mo baptisi rẹ Li Orukọ ti Babba, ati ni ti Ọmmọ, ati ni ti Ẹmmí Mimọ́. Amin.

Nigbana li Alufa o wipe.

AWA gbà eleyi sinu ijọ agbo Kristi,* awa sì sà a li àmi Agbelebu, apẹrẹ pe nikẹhin kì

* Nihinyi ni ki Alufa ki o sàmi Agbelebu si oluwarẹ ni iwaju.

Digitized by Google

yio tiju lati jẹwọ igbagbọ́ Kristi ti a kàn mọ́ agbelebu, ati lati ba ẹ̀ṣẹ, aiye, ati èṣu jà bi ọkọnri labbẹ ọpágun rẹ̀; ki o sì duro bi ọmmọ ogun Kristi nitõtọ, ati bi ọmmọ ọdọ rẹ̀ titi opin ẹmmí rẹ̀ li aiye yi. Amin.

Nigbana li Alufa o wipe.

KI ẹnyin ki o wò o nisisiyi, arakọnri olufẹ ọwọn, pe *awọn enia wọnyi* di atunda, a sì lọ́ *wọn* sinu ara ti Ijọ awọn enia Kristi, ẹ jẹ ki awa ki o dupẹ fu Ọlọrun Olodumare nitori ore wọnyi, ki a sì fi ọkkàn kan gbadura sọdọ rẹ̀, ki awọn enia wọnyi ki o le ma rìn ọjọ ẹmmí wọn iyokù gẹgẹ bi ipilẹṣẹ yi.

¶ *Gbogbo enia nkunlẹ a o gbà Adura Oluwa pe.*

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọ̀wọ li orukọ rẹ. Ijọbba rẹ de. Ifẹ́ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ojọ wa loni. Dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa, Bi a ti ndari ẹ̀ṣẹ jì awọn ti o ṣẹ̀ wa. Má fà wa sinu idẹwò; Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin. Amin.

Nigbana li Alufa o wipe.

TỌKKÀN-TỌKKÀN li awa fi ndupẹ lọwọ́ rẹ, Babba alãnu julọ, nitori ti iwọ fiyesi i lati pè wa si ìmọ ore-ọfẹ rẹ, ati si igbagbọ́ rẹ; Sọ ìmọ yi di pupọ̀, ki iwọ ki o sì ma fi igbagbọ́ yi gunlẹ ninu wa siwaju. Fi Ẹmmí Mímọ́ rẹ fu *awọn enia wọnyi;* pe bi *nwọn* ti di atunbi, ti a sì sọ *wọn* di ijogún igbala ti kò nipẹkun, nipa Jesu Kristi Oluwa wa, ki *nwọn* ki o le ma ṣe ọmmọ ọdọ rẹ titi, ki *nwọn* ki o sì ri ileri rẹ gbà; nitori Oluwa wa na Jesu Kristi Ọmmọ rẹ, ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu iwọ, ni iṣọkan Ẹmmí Mímọ́ na lailai. *Amin.*

Digitized by Google

Nigbana ni gbogbo enia dide duro, Alufa o wi iyanju yi fu awọn Onigbọwọ pe.

NJẸ bi awọn enia wọnyi ti ṣe ileri li oju nyin lati kọ̀ èṣu ati gbogbo iṣẹ́ rẹ̀ silẹ, lati gbà Ọlọrun gbọ́, ati lati ma sìn i; ki ẹnyin ki o sì ma ranti pe, ipa ati iṣẹ́ ti nyin ni lati ma rán *wọn* letí, ni ipinhun, ileri, ati ijẹwọ ironu, ti *nwọn* ṣe nisisiyi li oju ijọ awọn enia Ọlọrun yi, ati pẹlu-pẹlu li oju ẹnyin ẹlẽri *wọn* ti *nwọn* yàn. Ati ki ẹnyin ki o sì ma pè *wọn*, lati ma lò agbara *wọn*, lati ma tọ̀pa bi a o ti ma kọ́ *wọn* nitõtọ ninu Ọ̀rọ mimọ́ Ọlọrun; ti *nwọn* o fi ma dàgba bẽ̀ ninu ore-ọfẹ, ati ni ìmọ Jesu Kristi Oluwa wa, ki *nwọn* ki o sì ma wà ninu iwa-bi-Ọlọrun, li ododo, ati li aìrekọja, li aiye isisiyi.

O sì wi fu awọn ẹniti *a baptisi ni titun pe.*

ATI fu *ẹnyin*, nipa Baptismu ẹniti o mu Kristi wọ̀, ipa ati iṣẹ́ ti *nyin* sì ni pẹlu, bi ati sọ *nyin* di *ọmmọ* Ọlọrun ati ọmmọ imọlẹ, nipa igbagbọ́ Jesu Kristi, lati ma rìn bi o ti yẹ si ìpe *nyin* si isìn Kristian, ati bi o ti yẹ si ọmmọ imọlẹ; ki *ẹnyin* ki o ma ranti nigba-gbogbo pe, Baptismu li ṣapẹrẹ ijẹwọ wa; eyi-ni ni, lati ma tọpasẹ Jesu Kristi Olugbala wa, ati lati sọ wa dabi rẹ̀; pe bi o ti kú, ti o sì tún jinde fu wa; bẽli awa, ti a baptisi, iba sì ma di okú fu èṣẹ, ki a sì tún jinde sinu ododo; nigba-gbogbo ki awa ki o sì ma pọn gbogbo ifẹ́ buburu ati ifẹkufẹ ọkàn loju, ati ki awa ki o sì ma rìn lọ siwaju li ọjọ gbogbo ninu atọrun-wa ìwa gbogbo, ati ninu ìwa-bi-Ọlọrun.

Digitized by Google

KATEKISMU

TI

IJỌ ENIA ỌLỌRUN.

Ibère. Orukọ rẹ?

Idahùn. N. tabi M.

Ibère. Tani fi orukọ yi fu ọ?

Idahùn. Awọn Babba mi nipa ti Ọlọrun, ati awọn Iya mi nipa ti Ọlọrun, ninu baptismu mi; nipa eyi ti asọ mi di ara ẹyà Kristi kan, Ọmmọ Ọlọrun, ati ijogun ijọbba Ọlọrun.

Ibère. Njẹ kini awọn babba rẹ nipa ti Ọlọrun ati awọn iya rẹ nipa ti Ọlọrun ṣe fu ọ?

Idahùn. Nwọn ṣe ileri, nwọn sì jẹ' jẹ ohun mẹta li orukọ mi. Ekini, pe, emi o kọ Èṣu ati gbogbo iṣẹ rẹ̀ silẹ, irera ati ogo asan aiye buburu yi, ati gbogbo ifẹkufẹ èṣẹ ara. Ekeji, pe, emi o gba gbogbo otitọ, igbagbọ́ Kristian gbọ́. Ati Ẹkẹta, pe, emi o pa ifẹ́ mimọ́ Ọlọrun ati ofin rẹ̀ mọ́, emi o sì ma rìn ninu ikana li ọjọ aiye mi gbogbo.

Ibère. Iwọ kò ha rò pe iṣẹ́ rẹ ni lati gbagbọ́ ati lati ṣe bi nwọn ti ṣe ileri fu ọ?

Idahùn. Nitõtọ; ati nipa iranlọwọ Ọlọrun emi o ṣe bẽ. Emi sì fi tọkkàn-tọkkàn dupẹ lọwọ́ Babba wa ti mbẹ lọrun, ti o ti pè mi si ipa igbala yi nipa Jesu Kristi Olugbala wa. Emi sì gbadura si ọdọ Ọlọrun lati fu mi li ore ọfẹ rẹ̀, ki emi ki o le wà titi ninu ikana de ipẹkun aiye mi.

Ibère. Wi otitọ igbagbọ́ rẹ?

Digitized by Google

Idahùn. Mo gbà Ọlọrun Babba Olodumare gbọ́, Ẹlẹda ọrun on aiye.

Mo gbà Jesu Kristi gbọ́, Ọmmọ rẹ̀ kanṣoṣo Oluwa wa, Ẹniti a fi Ẹmmí Mimọ́ loyun, Ẹniti a bí ninu Maria Wundia, Ẹniti o jiya lọwọ́ Pọntius Pilati; Ẹniti a kàn mọ́ agbelebu, Ẹniti o kú, ti a sì sin, O ṣọkalẹ re ipò okú; Ni ijọ́ kẹta otun jinde kuro ninu okú; O rè oke ọrun, O sì joko lọwọ́ ọtun Ọlọrun Babba Olodumare; Nibẹ̀ ni yio ti wá ba ãye on okú wijọ́.

Mo gbà Ẹmmí Mimọ́ gbọ́; Ati Ijọ́ Mimọ́ Enia Ọlọrun; Ati Idapọ awọn Enia Mimọ́; Idarijì ẹ̀ṣẹ̀; Ajinde ara ni isà okú, ati ìye ti kò nipẹkun. Amin.

Ibère. Kini iwọ́ kọ́ li olori ninu otitọ́ nwọnyi ti igbagbọ́ rẹ̀?

Idahùn. Ekini, Mo kọ́ lati gbà Ọlọrun Babba gbọ́, ẹniti o da mi ati gbogbo aiye.

Ekeji mo gbà Ọlọrun Ọmmọ́ gbọ́, ẹniti o ra mi pada, ati gbogbo araiye.

Ẹkẹta. Mo sì gbà Ọlọrun Ẹmmí Mimọ́ gbọ́, ẹniti o sọ́ mi di mimọ́ ati gbogbo ayànfẹ́ enia Ọlọrun.

Ibère. Iwọ́ wipe awọn babba rẹ̀ nipa ti Ọlọrun ati awọn iya rẹ̀ nipa ti Ọlọrun ṣe ileri fu ọ́ pe, iwọ́ o pa ofin Ọlọrun mọ́. Wi fu mi melo ni mbẹ̀?

Idahùn. Mẹ̀wa.

Ibère. Ewo ni nwọn?

Idahùn. Ikanã ti Ọlọrun sọ́ ni Kapita ogun ti Ẹksọdus pe, Emi ni Jehofa Ọlọrun rẹ̀ ti o mu ọ́ jade kuro ni ilẹ̀ Egypti, lati oko ẹru jade wá.

Ibère. Ewo ni ofin ekini?

Idahùn. Iwọ́ kò gbọdọ́ ni Ọlọrun miran pẹlu mi.

Digitized by Google

Ibère. Ewo ni ofin ekeji?

Idahùn. Iwọ kò gbọdọ ya ere-kere fu ara rẹ, tabi aworan ohun kan ti mbẹ loke ọrun, tabi ti ohun kan ti mbẹ ni isalẹ ilẹ; tabi ti inu omi ti mbẹ nisalẹ ilẹ; Iwọ kò gbọdọ tẹ ara rẹ ba fu nwọn bẽni iwọ kò gbọdọ sìn wọn: nitori emi Jehofa Olọrun rẹ, Olọrun owu ni mi ti mbẹ èṣẹ awọn babba wò lara ọmmọ, lati iran-de-iran kẹta ati èkẹrin ninu awọn ti o korira mi. Emi a sì ma fi anu hàn fu ẹgbẹgbẹrun awọn ti o fẹ mi, ti nwọn sì pa ofin mi mọ.

Ibère. Ewo ni ofin ẹkẹta?

Idahùn. Iwọ kò gbọdọ pè orukọ Jehofa Olọrun rẹ lasan; nitori ti Jehofa kì yio mu awọn ti o pè orukọ rẹ lasan li alli èṣẹ lọrùn.

Ibère. Ewo ni ofin ẹkẹrin?

Idahùn. Ranti ọjọ isimi lati lò o ni mimọ. Ijọ mẹfa ni iwọ ọ ṣiṣẹ, ti iwọ o sì ṣe iṣẹ rẹ gbogbo; Ṣugbọn ijọ ekeje li ọjọ isimi Jehofa Olọrun rẹ. Ninu rẹ, iwọ kò gbọdọ ṣe iṣẹkiṣẹ kan, iwọ, tabi ọmmọ rẹ ọkọnri, tabi ọmmọ ọdọ rẹ obiri, ọmmọ ọdọ rẹ ọkọnri, tabi ọmmọ ọdọ rẹ obiri, tabi ohun ọsin rẹ, tabi alejò rẹ ti mbẹ ninu ibode rẹ. Nitori ni ijọ mẹfa li Jehofa da ọrun on aiye, okun ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu nwọn, o sì simi ni ijọ ekeje: nitori na ni Jehofa ṣe busi ijọ ekeje, o sì yà a si mimọ.

Ibère. Ewo ni ofin akarun?

Idahùn. Bọwọ fu babba on iya rẹ: ki ọjọ rẹ ki o le pẹ ni ilẹ ti Jehofa Olọrun rẹ fifu ọ.

Ibère. Ewo ni ofin ẹkẹfa?

Idahùn. Iwọ kò gbọdọ pania.

Ibère. Ewo ni ofin ekeje?

Idahùn. Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga.

Ibère. Ewo ni ofin ẹkẹjọ?

Idahùn. Iwọ kò gbọdọ jale.

Digitized by Google

Ibère. Ewo ni ofin ẹkẹsan?

Idahùn. Iwọ kò gbọdọ jẽri eke si ẹnikeji rẹ.

Ibère. Ewo ni ofin ẹkẹwa?

Idahùn. Iwọ kò gbọdọ ṣojukòkoro si ile ẹnikeji rẹ iwọ kò gbọdọ ṣojukòkoro si aya ẹnikeji rẹ, tabi si ọmmọ ọdọ rẹ ọkọnri, tabi si ọmmọ ọdọ rẹ obiri, tabi si malu rẹ tabi si kẹtẹkẹtẹ rẹ, tabi si ohun gbogbo ti iṣe ti ẹni keji rẹ.

Ibère. Kini iwọ kọ́ li olori nipa ofin nwọnyi?

Idahùn. Mo kọ́ nkan meji, isìn mi nipa ti Ọlọrun, ati isìn mi nipa ẹnikẹji mi.

Ibère. Kini isìn rẹ nipa ti Ọlọrun?

Idahùn. Isìn mi nipa ti Ọlọrun ni, lati ma gbà a gbọ́, lati ma bẹ̀ru rẹ, ati lati ma fi gbogbo aya, gbogbo ìye, gbogbo ọkkàn, ati gbogbo agbara mi fẹ ẹ, lati ma bọ ọ, lati ma dupẹ fu u, lati ma gbé gbogbo ẹkẹ mi lẽ, lati ma pe orukọ rẹ, ati lati ma bọ̀wọ fu orukọ mimọ́ rẹ ati òrọ rẹ, ati lati ma sìn i lododo li ọjọ aiye mi gbogbo.

Ibère. Kini isìn rẹ nipa ẹnikeji rẹ?

Idahùn. Isìn mi nipa ẹnikeji mi ni, lati ma fẹ ẹ bi emi tikara mi, ati lati ma ṣe si gbogbo enia, bi mo ti fẹ ki nwọn ko ṣe si mi. Lati ma fẹ, lati ma bu ọlá, ati lati ma ran babba ati iya mi lọwọ́: lati ma bu ọlá ati ma gbà Ọbba gbọ́, ati gbogbo awọn ti a fi si abbẹ oyè rẹ; Lati ma tẹ̀ri ara mi ba fu gbogbo awọn alakoso mi, awọn olukọ mi, awọn onisẹ Ọlọrun, ati awọn olori mi: Lati ma rẹ ara mi silẹ, lati ma bọ̀wọ fu gbogbo awọn ti o san ju mi lọ: Ki nma ti ipa òrọ tabi iṣe mi pa ẹnikẹni lara: Lati ma ṣe õtọ ati ododo ni gbogbo iṣe mi: Ki nma ro ero buburu tabi irira li ọkkàn mi: Lati ma pa ọwọ́ mi mọ́ kuro ni hihe ati ni jijale, ati ahọn mi kuro ni

Digitized by Google

sisọ ọrọ ibi eke, ati ṣiṣata: Lati ma wà ni titẹnu alrekọja, ati alleri; Ki nma ṣojukokorò, tabi ki nma fẹ ini ẹlomiran ṣugbọn ki nkọ lati ma ṣiṣẹ lododo, lati ni ini mi, ati lati ma jẹ isìn mi ni iru iwà ti inu Ọlọrun yio dùn lati pè mi si.

Ibère. Ọmmọ mi rere, o mọ eyi, pe, iwọ kò le ṣe nkan nwọnyi fu ara rẹ, bẹ̀ni iwọ kò le rìn ninu ofin Ọlọrun, ki iwọ ki o sì sìn i, li alsi ore ọfẹ rẹ papa, pe iwọ o ma kọ́ nigbà gbogbo lati ma kigbe pẽ ninu adura li alṣiyemeji: njẹ, jẹ ki emi gbọ́, bi iwọ ba le kà adura Oluwa?

Idahùn. Babba wa, ti mbẹ li ọrun: Ọ̀wọ li orukọ rẹ. Ijọbba rẹ dẹ: Ifé ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ojọ wa loni. Dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa, bi ati ndari ẹ̀ṣẹ jì awọn ti o ṣẹ̀ wa. Má fa wa sinu idẹwò; ṣugbọn gbà wa ninu tulasi. Amin.

Ibère. Kini iwọ nfẹ lọwọ́ Ọlọrun ninu adura yi?

Idahùn. Emi nfẹ lọwọ́ Oluwa Ọlọrun mi, Babba wa ọrun, ẹniti isẹ olufuni gbogbo ore, lati rán ore ọfẹ rẹ si mi, ati si gbogbo enia, ki a le ma bọ ọ, ki a sìn i, ki a sì gbà a gbọ́ bi o ti yẹ ki a ṣe: Emi sì gbadura si ọdọ Ọlọrun, ki o le rán gbogbo nkan si wa, ti o yẹ fu ọkkàn ati fu ara wa; ati ki o le ṣanu fu wa, ki o sì dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa, ati pe, ki o sì ṣe didùn inu rẹ lati gbà wa là ati lati dãbò bò wa ninu gbogbo ewu ti ẹmmí ati ti ara, ati pe ki o sì pa wa mọ́ kuro ninu gbogbo ẹ̀ṣẹ ati ìwà ikà, ati lọwọ́ ọtá wa ẹmmí, ati lọwọ́ ikú alnipẹ̀kun. Emi sì ni igbẹkẹ le si eyi pe, on yio ṣe e nipa anu ati ore rẹ, nitori Oluwa wa Jesu Kristi. Nitorina ni mo sì ṣe wi pe, Amin; *Bẽni ki o ri.*

Digitized by Google

Ibère. Sakramenti melo ni Kristi da silẹ ninu ijọ enia rẹ?

Idahùn. Meji peré, ti o yẹ gbogbo fu igbala; eyini ni, Ibaptismu ati Onjẹ-ale Oluwa.

Ibère. Bi iwọ ti mọ idi ọrọ Sakramenti yi si?

Idahùn. Emi mọ idi rẹ si amì ode ti a nri ti ore ọfẹ kan ti inu, ati ti ẹmmí ti a fi fu wa, ti Kristi tikararẹ da silẹ, bi ọna nipa eyi ti awa ri ikana gbà ati àmi lati mu u ki o da wa loju.

Ibère. Ipa melo ni mbẹ ninu Sakramenti?

Idahùn. Meji, àmi ode ti a nri, ati ore ọfẹ na ti ẹmmí ti inu ti a kò ri.

Ibère. Ewo ni àmi ode ti a nri, tabi iṣe ninu baptismu?

Idahùn. Omi: ninu eyi ti a baptismu enia na li orukọ Babba, ati niti Ọmmọ ati niti Ẹmmí Mimọ.

Ibère. Ewo ni ore ọfẹ ti inu; ati ti ẹmmí?

Idahùn. Ikú si ẹ̀ṣẹ̀, ati íbi titun si ododo: nitori nipa ẹda, ninu ẹ̀ṣẹ̀ li a bí wa si, ati ọmmọ ibinu, ati ipa yi sọ wa di ọmmọ ore ọfẹ.

Ibère. Kini abère lọwọ enia ti a o baptisi?

Idahùn. Ironupiwada, nipa eyiti nwọn kọ ẹ̀ṣẹ̀ silẹ; ati igbagbọ, nipa eyiti nwọn gbà gbogbo ileri Ọlọrun, ti a ṣe fu wọn gbọ, girigiri ni sakramenti na.

Ibère. Njẹ nitori kini a ṣe nbaptismu ọmmọ ọwọ, nigbati nwọn kò kiyesi wọn nitori ọgbọgbọ ọdun wọn?

Idahùn. Nitori awọn onigbọwọ wọn ṣe ileri fu nwọn: ileri eyiti, nigbati nwọn ba dagbà, iṣẹ awọn tikara nwọn ni lati kiyesi.

Ibère. Nitori kini a ṣe da sakramenti Onjẹ-alẹ Oluwa silẹ?

Idahùn. Nitori iranti irubọ ikú Kristi titi, ati ireti ti a nri gbà ninu rẹ.

Digitized by Google

Ibère. Ewo ni ipa ode tabi àmi Onjẹ-alẹ Ọluwa?

Idahùn. Akara ati ọti Wain, ti Ọlọrun ti pa wa lasẹ lati ma gbà.

Ibère. Kini ipa ti inu tabi ohun apẹrẹ rẹ?

Idahùn. Ara ati ẹjẹ Kristi, ti awọn olododo ngbà lõtọ ati li ododo li Onjẹ-alẹ Oluwa.

Ibère. Kini ire ti o wà ninu rẹ ninu eyiti awa iṣe alabapin?

Idahùn. Ilera ati itura ọkkàn wa nipa ti ara, ati ẹjẹ Kristi, gẹgẹ bi akara ati ọti wain ti ri fu ara wa.

Ibère. Kini a bère lọwọ awọn ti yio wá ibi Onjẹ-alẹ Oluwa?

Idahùn. Lati wá idi ara nwọn jalẹ koro bi nwọn ba ronupiwada ẹṣẹ wọn atijọ li ododo, ti nwọn sì gbèro girigiri lati ma wà li ọtún iwà, ti nwọn sì ni igbagbọ́ gbigbona ninu anu Ọlọrun nipa Kristi pẹlu iranti ti o ni ọpẹ ti ikú rẹ, ti wọn sì wà ni ifé si gbogbo enia.

Digitized by Google

IṢẸ́ TI KỌNFIRMATION.

TABI IFI ỌWỌ́ LE AWỌN TI ATI BAPTISI TI WỌN DÀGBA DE ỌDUN ATI GBÀ ILERI NA FU ARA WỌN.

¶ *Li ọjọ́ na ti ati yàn, gbogbo awọn ti a o konfirm, ti a fi wọn si ipò wọn, ti wọn sì duro rere, niwaju Bịṣọpu; nigbana ni on (tabi Alufa miran ti on yàn) ẹ yio kà ọ̀rọ̀ àtẹle wọnyi.*

NITORI ki ìsin Konfirmation ko le jasi imuduro awọn ti yio gbà a, awọn ijọ enia Ọlọrun rò pe o dara lati paṣẹ pe, ki a má ṣe konfirm ẹnikẹni, bikoṣe awọn ti wọn le kà Igbagbọ́, Adura Oluwa, ati Ofin mẹwa; ti nwọn sì le dahun ibère miran bi iru eyiti o wà ninu Katekismu kukuru ni: aṣẹ eyiti o ṣe anfani jọjọ lati kiye si; nitori bi awọn ọmmọde ti wá de ọdun àgba wọn wayi, bi nwọn sì ti kọ́ ohun ti Babba ati Iya wọn nipa ti Ọlọrun ti ṣe ileri fu wọn ni ibaptisi wọn, ki awọn tikara wọn, lati ẹnu wọn, ati ifẹ́ ọkkàn wọn wá, nigbangba loju ijọ enia Ọlọrun, tún jẹwọ́ ọkan na; ki nwọn ki o sì ṣe ileri pe nipa ore-ọfẹ Ọlọrun, lati isisiyi lọ, awọn o mura lododo lati kiyesi iru ohun wọn-ni, nipa ijẹwọ́ awọn tikara wọn, ti nwọn gbà lati ṣe.

Digitized by Google

¶ *Nigbana ni Biṣọpu yio wipe,*

NIHINYI, niwaju Ọlọrun ati ijọ enia yi, ẹnyin ha tún fẹ ṣe ileri on ati jẹ'jẹ ti ati jẹ lorukọ nyin ninu ibaptisi nyin; ki ẹnyin tikara nyin ko tun fi ọkkan na mulẹ, ki ẹ si jẹwọ pe, ẹnyin kò gbọdọ ṣàlma gbagbọ́, ati lati ṣe ohun gbogbo ti awọn Babba ati Iya nyin nipa ti Ọlọrun ti gbà fu nyin?

¶ *Olukuluku wọn ni yio sì dahùn soke wipe,*

Emi fẹ.

Biṣọpu na.

IRANLỌWỌ wa mbẹ li Orukọ Oluwa.

Idahùn. Ti o da ọrun on aiye.
Bishop. Ibukún ni fu Orukọ Oluwa.
Idahùn. Lati isisiyi lọ aiye alnipẹkun.
Bishop. Oluwa gbọ́ adura wa.
Idahùn. Ko sì jẹ ki igbe wa ko wá si ọdọ rẹ.

Biṣọpu na. Ẹ jẹ ka gbadura.

OLODUMARE ati lai Ọlọrun alãye, iwọ ti o ti fiyèsi i lati ṣe atunbi awọn ọmmọ ọdọ rẹ wọnyi nipa Omi ati Ẹmmí Mimọ́, ti o sì ti dari gbogbo èṣẹ wọn jì wọn. Ṣatilẹhin wọn, awa mbẹ ọ, Oluwa, nipa Ẹmmí Mimọ́ Olutunu ni, ki o sì jẹ ki ọpọlọpọ ore-ọfẹ rẹ ko ma bi si i ninu wọn lojojumọ; ẹmmí ọgbọn ati ti òye; ẹmmí imọràn ati ti agbara; ẹmmí imọ ati ti iwàbi-Ọlọrun otitọ; ki o sì fi ẹmmí ibẹ̀ru mimọ́ rẹ kún wọn Oluwa, nisisiyi ati lailai. *Amin.*

Digitized by Google

¶ *Nigbana ni gbogbo nwọn yio kunlẹ niwaju Bişọpu, yio sì fi ọwọ́ rẹ̀ le olukuluku wọn li ori l'ọkọkan o nwi pe,*

OLUWA fi ore-ọfẹ rẹ ọrun dãbo bo ọmmọ rẹ yi [tabi Ọmmọ ọdọ rẹ yi] ki on ki o le jẹ ti rẹ lailai: lojojumọ ni ki on ma pọ̀ si i l'ẹbun Ẹmmí Mimọ́ rẹ titi lọ titi on o fi de ijọba rẹ alnipẹkun. *Amin.*

¶ *Nigbana ni Bişọpu yio wipe,*

Ki Oluwa ko pẹlu nyin.
Idahùn. Ki o sì pẹlu ẹmmí rẹ.

¶ *Ẹ jẹ ki a gbadura.*

BABBA wa ti mbẹ lọrun, Ọ̀wọ li orukọ rẹ Ijọba rẹ de. Ifẹ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ojọ wa loni. Dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa, bi ati ndari ẹ̀ṣẹ jì awọn ti o ṣẹ̀ wa. Má fà wa sinu idẹwò; Ṣugbọn gbà wa ninu tulàsin. *Amin.*

Adura yi pẹlu.

OLODUMARE ati lai Olọrun alãye, ẹniti o mu wa lati fẹ on ati ṣe ohun wọn-ni ti o dara ti o sì ṣe itẹwọgbà fu Olla-nla mimọ́ rẹ; Awa fi iparamọ bẹ̀bẹ lọdọ rẹ fu awọn ọmmọ ọdọ rẹ nwọnyi, laraẹniti (gẹgẹ bi awọn Apostili mimọ́ rẹ) awa ti gbé ọwọ́ wa le nisisiyi ki o le da wọn loju (nipa àmi yi) niti oju rere ati ore rẹ si wọn. Awa mbẹ ọ, jẹ ki ọwọ́ rẹ bi ti babba ko ma wà lara wọn titi; jẹ ki Ẹmmí

Digitized by Google

Mimọ́ rẹ ko ma wà pẹlu wọn titi; ki o sì fà wọn bẹ̃bẽ̃ sinu imọ̀ ati igbọ́ràn òrọ rẹ, nigbẹhin ki nwọn ki o le ni ìye alnipẹkun; nipa Oluwa wa Jesu Kristi, ẹniti o wà ti o sì njọbba pẹlu Iwọ ati Ẹmmí Mimọ́, lai Ọlọrun kan, aiye alnipẹkun. *Amin.*

Oluwa Olodumare, ati aiyeraiye Ọlọrun, fiyesi i awa mbẹ ọ, lati ṣe ilàna, ati lati sọ wa di mimọ́, on ati tọ́ at'ọkkàn at'ara wa lọ̀na ofin rẹ; pe, nipa ipá ipamọ́ agbara rẹ julọ, nihin, ati titi lai ki a le pa at'ara at'ọkkàn wa mọ́; nitori Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi. *Amin.*

¶ *Nigbana ni Bishop yio sure fu wọn wi* * *bayi pe,*

IBUKÚN Ọlọrun Olodumare, ti Babba, ti Ọmmọ, ati ti Ẹmmí Mimọ́ ko ma wà lori nyin, ki o sì ma ba nyin gbé titi lailai. *Amin.*

Digitized by Google

IṢẸ́ TI ISOYIGI.

¶ *Ni ijọ Ọlọrun mẹta ṣaju isoyigi, ki Alufa ki o fi i lọ li oju Ijọ awọn enia Ọlọrun, ki o sì wi pe.*

MO fi isọfu ti isoyigi lọ ti M. —— ara —— ati ti N —— ara ——. Bi ẹnikẹni ninu nyin ba mọ idí, tabi ohun idina tõtọ kan, nitori eyiti a kì yio le fi Isoyigi mimọ́ dà awọn enia meji yi pọ̀, ki ẹnyin ki o wi tẹlẹ niwoyi. Eyiyi ni igba ekini (*ekeji*, tabi *ẹkẹta*) ifilọ̀.

¶ *Ni igba ti isoyigi li Alufa o wipe.*

OLUFẸ̀ ọwọn, awa pejọ nihinyi niwaju Ọlọrun, ati li oju ijọ yi, lati dà Ọkọnri yi ati Obiri yi pọ̀ ni Isoyigi mimọ́; ti ṣe ìwa ti o li ọllá, ti Ọlọrun ti da silẹ ni igba ìwa rere enia, ti o sì nfi eyi-ni ṣe akawe iṣọkan ọ̀rọ ijinlẹ ti Kristi on Ijọ awọn enia rẹ̀; ìwa mimọ́ na yi ti Kristi fi oju ara rẹ̀ ṣe li ọ̀ṣọ́, ti o sì ṣe li ẹwà, ati pẹlu iṣẹ́-iyanu àtetekọṣe, ti o ṣe ni Kana ti Galili; ati ìwa rere na ti Paulu yìn pe, o li ọllá ninu awọn enia gbogbo: ati nitori na, kò ṣe ohun ti a ba ma kùgbu ṣe, ti a ba fọwọ́le li alro tẹlẹ, bi ohun ti kò wuwo, tabi bi ohun afire-ṣe, lati ma bọ́ ifẹkufẹ ara enia, bi ẹranko ti kò ni iyè ninu; ṣugbọn tọ̀wọ́-tọwọ́, toye-toye, tìro-tiro ati ni pẹlẹ, ati ni ìbẹru Ọlọrun; ki a ma rò bi o ti yẹ nitori idí kili a ṣe da Isoyigi silẹ.

Digitized by Google

Idí ekini, A da a silẹ nitori ọmmọ bíbi, ti a o tọ́ ni ìbẹru ati ni ẹkọ́ ti Ọluwa, ati si iyìn Orukọ mimọ́ rẹ̀.

Idí ekeji, A da a silẹ ki o le ṣe ìdena si èṣe, ati ki a le yàna agbere silẹ; nitori pe irú awọn ẹniti kò li ẹ̀bun imaraduro, ki nwọn ki o soyigi, ki nwọn ki o sì pa ara wọn mọ́ li ẹ̀ya ara Kristi ti kò li ẽri.

Idí ẹkẹta, A da a silẹ fu àjumọ kẹgbẹ, iranlọwọ, ati itunu, ti o yẹ ki ẹnikini ki o ni si ẹnikeji, iba ṣe ni irọra ati ni ipọnju. Ninu ìwa mimọ́ yi li awọn enia meji yi wá si lati dà wọn pọ̀. Nitori na bi ẹnikan ba ri ohun ikọsẹ tõtọ kan, nitori eyiti a kì yio le fi dà wọn pọ̀ bi o ti tọ́ si nipa ofin, ki o ti iwoyi sọ tẹlẹ, bi kò sì ṣe bẽ lati oni lọ ki o pa ẹnu rẹ̀ mọ́ titi lai.

¶ *Alufa o sì wi fu awọn ẹniti a o so ni yigi pe.*

MO bère lọdọ ẹnyin mejeji, bi o ti ṣe pe ẹnyin o dahùn li ọjọ́ idajọ́ ti o li èru pipọ̀, nigbati ohun ìkọkọ ti gbogbo àiya enia yio ṣí silẹ, bi ẹnikan ninu ẹnyin mejeji ba mọ̀ ohun ikọsẹ kan, ti kì yio jẹ ki a dà nyin pọ̀ ni Isoyigi bi o ti yẹ si nipa ofin, ki o ti iwoyi jẹwọ rẹ̀. Nitori ki o le da nyin loju pe, iye awọn ti a ba dàpọ lọ si òdi si bi Ọrọ Ọlọrun ti là silẹ funi, a kò dà wọn pọ̀ nipa ti Ọlọrun; bẽni Isoyigi wọn kò si nipa ofin.

¶ *Bi ohun ikọsẹ kan kò ba si, nigbana li Alufa o wi fu Ọkọnri na pe.*

M. IWỌ nfẹ ni Obiri yi li aya rẹ̀ nipa Isoyigi, ki ẹnyin ki o jùmọ ma gbé pọ̀ nipa

Digitized by Google

idasilẹ Ọlọrun ni ìwa mimọ́ Isoyigi? Iwọ o ma fẹ ẹ, iwọ o ma tù u ninu, iwọ o ma bu ọlá fu u, ati ki iwọ ki o ma ṣe itọju rẹ, nigba arun ati nigba ilera; ki iwọ ki o sì kọ́ gbogbo awọn ẹlomiran silẹ, ki iwọ ki o sì fi ara mọ́ on nikanṣoṣo, titi iwọn igba ti ẹnyin mejeji o wà li aiye?

¶ *Ọkọnri na yio dahùn wipe,*

Mo fẹ.

¶ *Nigbana li Alufa o wi fu Obiri na pe.*

N. IWỌ nfẹ ni Ọkọnri yi li ọkọ rẹ nipa Isoyigi, ki ẹnyin ki o jùmọ ma gbé pọ̀ nipa idasilẹ Ọlọrun ni ìwa mimọ́ Isoyigi? Iwọ o ma gbọ́ ti rẹ̀, iwọ o ma sìn i, iwọ o ma fẹ ẹ, iwọ o ma bu ọlá fu u, ati ki iwọ ki o ma ṣe itọju rẹ, nigba arun ati nigba ilera; ki iwọ ki o sì kọ́ gbogbo awọn ẹlomiran silẹ, ki iwọ ki o sì fi ara mọ́ on nikanṣoṣo, titi iwọn igba ti ẹnyin mejeji o wà li aiye?

¶ *Obiri na yio dahùn wipe,*

Mo fẹ.

¶ *Nigbana li Alufa o wipe.*

Tali o fi Obiri yi fu Ọkọnri yi lati so o ni yigi?

¶ *Nigbana li Ọkọnri na yio fi ọwọ́ ọtún rẹ̀ gbà Obiri li ọwọ́ ọtún, o sì wi lẹhin Alufa pe.*

EMI M. fi isoyigi gbà iwọ N. li aya mi, lati ni ati lati mu, lati oni lọ, ti rere ati ti

Digitized by Google

buburu, ti ilọrọ̀ ati ti ipọnju, ninu arun ati ni ilera, lati fẹ ati lati kẹ, titi ikú o fi yà wa, gẹgẹ bi idasilẹ mimọ́ Ọlọrun; si eyi-ni mo fi otitọ mi fu ọ.

¶ *Nigbana li Obiri na yio sì fi ọwọ́ ọtún rẹ̀ gbà Ọkọnri li ọwọ́ ọtún, o sì wi lẹhin Alufa pe.*

EMI N. fi isoyigi gbà iwọ M. li ọkọ mi, lati ni ati lati mu, lati oni lọ, ti rere ati ti buburu, ti ilọrọ̀ ati ti ipọnju, ninu arun ati ni ilera, lati fẹ, lati kẹ, ati lati gbà ti rẹ gbọ́, titi ikú o fi yà wa, gẹgẹ bi idasilẹ mimọ́ Ọlọrun; si eyi-ni mo fi otitọ mi fu ọ.

¶ *Nigbana li Ọkọnri na yio fi Oruka si Obiri ni ika ẹkẹrin ti ọwọ́ òsin rẹ̀, o sì ndi Oruka na mu, o ma wi lẹhin Alufa pe.*

ORUKA yi ni mo fi ba ọ soyigi, ara mi li emi fi mbọllá fu ọ, ati ohun aiye mi gbogbo, iwọ ni mo fu: Li Orukọ ti Babba, ati ni ti Ọmmọ, ati ni ti Ẹmmí Mimọ́. Amin.

¶ *Awọn mejeji sì kunlẹ Alufa o wipe.*

Ẹ jẹ ki a gbadura.

OLỌRUN titi lai, Ẹlẹda ati Olupamọ gbogbo araiye, Olufuni li ore-ọfẹ ẹmmí gbogbo, Olorisọn ìye ti kò nipẹkun; Rán ibukún rẹ si ara awọn ọmmọ ọdọ rẹ wọnyi, ọkọnri yi ati obiri yi, awọn ẹniti awa nsùre fu li Orukọ rẹ; pe, bi Isaaki on Rebeka ti jùmọ gbé pọ̀ nitõtọ, bẽni ki awọn enia wọnyi nitõtọ ki nwọn ki o ma pa ipinhun ti nwọn ṣe mọ́, ati majẹmu

Digitized by Google

ti nwọn ba ara awọn mejeji dá (eyi ti a fi ifuni ati igbà Oruka ṣe ileri ati igbọwọ) ki nwọn ki o sì le jùmọ ma gbé pọ̀ ni ifẹ̀ afẹ̀tan ati li alafia, ki nwọn ki o le ma gbé bi ofin rẹ̀; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

¶ *Nigbana li Alufa yio dà ọwọ́ ọ̀tún wọn pọ̀, o sì wipe.*

AWỌN ẹniti Olọrun ba ti dàpọ̀ ṣọkan, ki ẹnikẹni ki o má ṣe yà wọn.

¶ *Nigbana li Alufa o wi fu awọn enia pe.*

NJẸ bi M. on N. ti jùmọ fi ohun ṣọkan ni isoyigi mimọ́, ti nwọn sì jẹ̃ri na niwaju Olọrun, ati li oju ijọ yi, ati si eyi-ni na ti nwọn sì fi otitọ̀ wọn fu ara wọn, ti nwọn sì gbà a, ti nwọn sì fi eyi-ni hàn ni fifuni ati ni gbigbà Oruka, ati ni idawọ-pọ̀; mo sọ pe, ki nwọn ki o ma gbé pọ̀ li Ọkọ ati li Aya, Li Orukọ ti Babba, ati ni ti Ọmmọ, ati ni ti Ẹmmí Mimọ́. Amin.

¶ *Ibukún.*

OLỌRUN Babba, Olọrun Ọmmọ, Olọrun Ẹmmí Mimọ́, ki o busi i fu nyin, ki o pa nyin mọ́, ki o sì ma ṣọ́ nyin; ki Oluwa ki o ma fi ãnu fi oju-rere rẹ̀ wò nyin; ki o sì ma fi èbe ati ore-ọfẹ ẹmmí gbogbo kún nyin bẽ, ki ẹnyin ki o le ma gbé pọ̀ bẽ li aiye yi, li aiye ti mbọ̀ ki ẹnyin ki o le ni ìye ti kò nipẹkun. *Amin.*

Digitized by Google

¶ *Nigbana li Alufa o kà Psalmu yi.*

Ibukún.

PSALMU 128.

IBUKÚN ni fu gbogbo ẹniti o bẹ̀ru JEHOFA; ti o sì nrìn li ọ̀na rẹ̀.

Nitori ti iwọ o jẹ ịṣẹ́ ọwọ́ rẹ : ninu irọra ni iwọ o sì ma gbé, yio sì dara fu ọ.

Obiri rẹ yio dabi ajara rere eleso pipọ̀, li ẹgbẹ ile rẹ : awọn ọmmọ rẹ yio dabi igi oróro yi tabeli rẹ ká.

Kiye si i, pe bẹ̀li a o busi i fu ọkọnri na, ti o bẹ̀ru JEHOFA.

JEHOFA yio busi i fu ọ lati Sion wá : ki iwọ ki o sì ma ri ire Jerusalemu li ọjọ aiye rẹ gbogbo.

Bẹ̀ni, ki iwọ ki o sì ma ri ati ọmmọ de ọmmọ rẹ, ati alafia lara Israeli.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ : ati fu Ẹmmí Mimọ́ ;

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẹ̀ni yio sì ma ri nigba-gbogbo : aiye àlnipẹkun. Amin.

¶ *Tabi Psalmu yi.*

Iṣẹ̀nu Ọlọrun.

PSALMU 67.

KI Ọlọrun ki o ṣẹ̀nu fu wa, ki o sì busi i fu wa ; ki o sì ṣe oju rẹ̀ ki o mọlẹ si wa lara.

Ki ọ̀na rẹ ki o le di mimọ̀ li aiye, ati igbala ilera rẹ ni gbogbo orilẹ ède.

Digitized by Google

Jẹ ki awọn enia ki o yìn ọ, Olọrun; jẹ ki gbogbo awọn enia ki o yìn ọ.

Jẹ ki inu awọn orilẹ ède ki o dùn, ki nwọn ki o sì ma kọnrin fu ayọ̀: nitori ti iwọ o fi ododo ṣe idajọ́ awọn enia, iwọ o sì jọbba awọn orilẹ ède li aiye.

Jẹ ki awọn enia ki o yìn ọ, Olọrun; jẹ ki gbogbo awọn enia ki o yìn ọ.

Nigbana ni ilẹ yio to ma mu asọnkún rẹ̀ wá; ati Olọrun, Olọrun wa tikara rẹ̀ yio busi i fu wa.

Olọrun yio busi i fu wa; ati gbogbo opin aiye yio sì ma bẹ̀ru rẹ̀.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí Mimọ́.

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẽni yio sì ma ri nigba-gbogbo: aiye alnipẹkun. Amin.

¶ *Nigbana Ọkọnri ati Obiri yio kunlẹ, Alufa nduro, o sì wipe.*

Alufa. Oluwa, ṣãnu fu wa.
Idahùn. Kristi, ṣãnu fu wa.
Alufa. Oluwa, ṣãnu fu wa.

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọ̀wọ li orukọ rẹ. Ijọbba rẹ de. Ifẹ́ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ojọ wa loni. Dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa, Bi a ti ndari ẹ̀ṣẹ jì awọn ti o ṣẹ̀ wa. Má fà wa sinu idẹwò; Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin. Amin.

Alufa. Oluwa, gbà awọn ọmmọ ọdọ rẹ, ọkọnri yi ati obiri yi là.

Idahùn. Awọn ẹniti ngbẹkẹ wọn le ọ.

Alufa. Oluwa, rán iranlọwọ si wọn lati ibi mimọ́ rẹ wá;

Digitized by Google

Idahùn. Ati titi lai ki iwọ ki o ma dãbobo wọn.

Alufa. Ki iwọ ki o ma ṣe odi agbara fu wọn.

Idahùn. Li oju awọn ọtá wọn.

Alufa. Oluwa, gbọ́ adura ti wa.

Idahùn. Ki o sì jẹ ki igbe wa ki o lọ si ọdọ rẹ.

Alufa.

OLỌRUN Abrahamu, Ọlọrun Isaaki, Ọlọrun Jakobu, ki o busi i fu awọn ọmmọ ọdọ rẹ wọnyi, ki o sì sú irugbin ìye ti kò nipẹkun si wọn li àiya; nitori pe ohun-kohun ti nwọn o fi ere kọ́ ninu Òrọ mimọ́ rẹ, ki nwọn ki o sì pa eyi na mọ́ nitõtọ. Oluwa, fi ãnu wò wọn lati ọrun wá, ki o sì busi i fu wọn. Ati bi iwọ ti rán ibukún rẹ si Abrahamu on Sara, fu itunu nla wọn, bẹ̃ni ki o sì fiye si i lati rán ibukún rẹ si awọn ọmmọ ọdọ rẹ wọnyi; bi nwọn ti ngbà ifẹ́ rẹ gbọ́, ti nwọn sì mbẹ li aìlewu labbẹ àbo rẹ nigba-gbogbo, ki nwọn ki o le ma wà ninu ifẹ́ rẹ titi opin ẹmmí wọn; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

¶ *Bi Obiri na ba kọja ọmmọ ibí ki a fò adura yi.*

OLUWA alãnu, ati Babba ọrun, nipa ore-ọfẹ ẹniti araiye mbisi i; Awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi ibukún rẹ ràn awọn enia mejeji yi lọwọ́, ki awọn mejeji ki o le kún fu irú ọmmọ bíbi, ati ki nwọn ki o sì ma gbé pọ̀ pẹ̀ bẹ̃ ni ifẹ́ bi-Ọlọrun ati nitõtọ, ki nwọn ki o sì le ma ri awọn ọmmọ wọn, ki a tọ́ wọn ni ìwa Kristian ati ni ìwa rere ọrun, fu iyìn ati ọlá rẹ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

OLỌRUN, iwọ ẹniti o ti ipa agbara rẹ ti inu asan da ohun gbogbo ; (lẹhin igbati ohun omiran tò lẹsẹsẹ,) ẹniti o sì yàn a pe, lara ọkọnri (ti a da bi aworan ati bi jijọ rẹ) ni ki obiri ki o ti ni ipilẹṣẹ rẹ ; bi iwọ sì ti dà wọn pọ, iwọ fi eyi-ni kọni pe, lai kò tọ nipa ofin lati yà awọn ẹniti iwọ fi isoyigi sọ-di ọkan : Ọlọrun, iwọ ti o ti yà ìwa Isoyigi si mimọ lati ṣe ohun ti o dara tobẹ nipa ọrọ ijinlẹ, pe ninu rẹ o sì ṣe akawe isoyigi nipa iṣọkan ninu Kristi on Ijọ awọn enia rẹ nipa ẹmmí ; Fi ãnu wò awọn ọmmọ ọdọ rẹ wọnyi, ati ki ọkọnri yi ki o fẹ aya rẹ, gẹgẹ bi Ọrọ rẹ, (bi Kristi ti fẹ iyawo, Ijọ awọn enia rẹ, ẹniti o sì fi ara rẹ fu u, ti nfẹ, ti o sì nkẹ ẹ gẹgẹ bi ara on tikara rẹ,) ati pẹlu ki obiri yi ki o ma fẹ, ki o sì ma hùwa ti o wùni, ki o ma ṣõtọ, ki o sì ma gbà ti ọkọ rẹ gbọ ; ati ni idakẹjẹ gbogbo, alàrekọja, ati alafia, ki o ṣe ọkan ninu awọn ọmmọ iya-agba mimọ oniwabi-Ọlọrun. Oluwa, bukún u fu awọn mejeji, ki o sì fifu wọn lati jogún ijọbba ọrun rẹ ti kò nipẹkun ; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

¶ *Nigbana li Alufa o wipe.*

OLỌRUN Olodumare, li àtetekọṣe, ẹniti o da Adamu on Efa, awọn õbi wa iṣaju, ti iwọ sì sọ wọn di mimọ, ti o sì dà wọn pọ ṣọkan ; Ki o dà ọrọ ore-ọfẹ rẹ si nyin lori, ki o sọ nyin di mimọ, ki o sì bukún u fu nyin ; ki ẹnyin ki o le ma wù u, ati li ara ati li ọkkàn, ki ẹnyin ki o sì ma gbé pọ ni ifẹ mimọ titi opin ẹmmí nyin. *Amin.*

Digitized by Google

¶ *Bi kò ba si Wasu, ki Alufa ki o kà eyi.*

GBOGBO ẹnyin ti à so ni yigi, tabi ẹniti nfẹ ìwa mimọ́ Isoyigi, ẹ gbọ́ bi Ọrọ Ọlọrun ti wi nipa iṣẹ́ ti awọn ọkọ si awọn aya wọn, ati nipa iṣẹ́ ti awọn aya si awọn ọkọ wọn.

Paulu, ni Episteli rẹ̀ si awọn ara Efesu, ni Kapu ẹkarun, o fi ofin yi fu gbogbo awọn ọkọlaya pe; Ẹnyin ọkọ, ẹ fẹ awọn aya nyin, gẹgẹ bi Kristi sì ti fẹ Ijọ awọn enia rẹ̀, ti o sì fi ara rẹ̀ fu u, ki o le sọ ọ di mimọ́, ki o sì le fi ìwẹ omi wẹ̀ ẹ nù, nipa Ọrọ na; nitori ki o le mu u fu ara rẹ̀ wá, ni Ijọ awọn enia ti o li ogo, li aìni abawọn, tabi ikiweje, tabi irú nkan ba wọn-ni; ṣugbọn ki o le mọ́, li aìni àbukun. Bẹ̃li o tọ́ ki awọn ọkọnri ki o ma fẹ awọn aya wọn bi ara awọn tikara wọn. Ẹniti o fẹ aya rẹ̀ o fẹ ara rẹ̀: nitori ti kò si ọkọnri kan ti o ti korira ara rẹ̀, bikoṣepe ki o ma bọ́ ọ, ki o sì ma kẹ ẹ, gẹgẹ bi Oluwa ti mbọ́ ti sì nkẹ Ijọ awọn enia rẹ̀: nitori awa li ẹ̀ya ara rẹ̀, ẹran ara rẹ̀, ati egungun ara rẹ̀.

Nitori idí eyi li ọkọnri ṣe fi babba ati iya rẹ̀ silẹ, ti yio sì dàpọ mọ́ aya rẹ̀; awọn mejeji a sì di ara kan. Ọrọ ijinlẹ nla li eyi; ṣugbọn emi nsọ ti Kristi on Ijọ awọn enia rẹ̀. Ṣugbọn, ki olukuluku nyin ki o fẹ aya rẹ̀ bẹ̃, gẹgẹ bi on tikara rẹ̀.

Gẹgẹ bẹ̃ni Paulu na, nigbati nkọwe si awọn ara Kolose, o wi bayi fu gbogbo awọn ọkọlaya pe; Ẹnyin ọkọ, ẹ fẹ awọn aya nyin, ki ẹ máṣe korò si wọn.

Ẹnyin sì gbọ́ bi Peteru, Aposteli Kristi, ẹniti on tikara rẹ̀ ṣe ọkọlaya, bi o ti wi fu gbogbo awọn ti ṣe ọkọlaya pe; Ẹnyin ọkọ, ẹ ma ba awọn aya nyin gbé gẹgẹ bi ìmọ; ẹ ma fi ọlá fu aya, bi ohun ìlo ti kò lera, ati bi ẹniti

Digitized by Google

àjumọ ṣe arole ti ore-ọfẹ ìye, ki adura nyin ki o má duro.

Titi o fi di ìsisiyi ẹnyin ti ngbọ́ iṣẹ́ ọkọ sipa ti aya rẹ̀. Njẹ bẹ̃, ẹnyin aya, ẹ gbọ́, ki ẹnyin ki o sì kọ́ iṣẹ́ nyin sipa awọn ọkọ nyin, gẹgẹ bi a ti gbé e kalẹ ninu Ọrọ Ọlọrun.

Paulu, ninu Episteli na ti a tète darukọ si awọn ara Efesu, o kọ́ nyin bayi pe; Ẹnyin aya, ẹ tẹriba fu awọn ọkọ nyin, bi ẹnipe fu Oluwa. Nitori ọkọ li olori aya, gẹgẹ bi Kristi ti ṣe olori ti Ijọ awọn enia rẹ̀: on sì li Olugbala ti ara. Nitori na bi Ijọ awọn enia rẹ̀ ti tẹriba fu Kristi, bẹ̃ni ki awọn aya ki o ma ṣe si ọkọ wọn li ohun gbogbo. O sì tún wipe, Jẹ ki aya ki o kiye si i lati mã bọ̀wọ fu ọkọ rẹ̀.

Ati ni Episteli rẹ̀ si awọn ara Kolose, Paulu fi ẹkọ́ kukuru yi fu nyin pe; Ẹnyin aya, ẹ tẹriba fu awọn ọkọ nyin, bi o ti yẹ nipa ti Oluwa.

Peteru pẹlu kọ́ nyin gidigidi, o wi bayi pe; Ẹnyin aya, ẹ tẹriba fu awọn ọkọ nyin; nitori pe, bi ẹnikan kò ba gbà Ọrọ na gbọ́, ki a le fi ìwa ti awọn aya yi i pada li alfi ti Ọrọ na ṣe; nigbati nwọn ba nkiye si ìwa nyin ti kò li ẽri, ti o dàpọ ti on ti èru. Ọṣọ́ ẹniti, ki a má jẹ ki o ṣe ọṣọ́ ode ni ti ori didì, ati ni ti ọṣọ́ wura wiwọ̀, tabi ọṣọ́ wiwọ̀; bikoṣepe ki o ṣe ọkọnri ni ti o pamọ́ li ọkkàn, li eyi ti kì idibajẹ; ọṣọ́ ìwa tutù, ati ọkkàn pẹlẹ, niwaju Ọlọrun ohun ti o niye nla. Nitori irú ipa eyi li awọn obiri mimọ́ igbani pẹlu, ti nwọn gbẹkẹle Ọlọrun, nṣe ara wọn li ọṣọ́, nwọn ntẹriba fu ọkọ wọn; gẹgẹ bi Sara ti gbà ti Abrahamu gbọ́, ti o npè e li Oluwa; ọmmọbiri ẹniti ẹnyin ṣe ni bi ẹ ti nṣe rere lọ si, ti ẹnyin kò sì fi ipaiya bèru-kẹru.

Digitized by Google

IṢẸ́ ISIN TI AWỌN OKÚ.

¶ *Ẹ kiye si i, a kì ikà iwe yi si okú ẹniti a kò baptisi rẹ̀, ati ẹniti a ṣatì nipa ofin ti Ijọ awọn enia Ọlọrun, ati ẹniti o pa ara rẹ̀.*

Nigbana li Alufa o sì wipe.

OLUWA wipe, Emi li ajinde ati ìye: ẹniti o ba gbà mi gbọ́, bi o tilẹ kú, ṣugbọn yio yè: ẹnikẹni ti o ba sì mbẹ lãye, ti o ba sì gbà mi gbọ́, kì yio kú lailai. *Joh.* 11. 25, 26.

EMI mọ̀ pe Oludande mi mbẹ, ati pe on yio sì duro lori ilẹ lẹhin ọla. Nipa ti ara mi, bi kòkoro tilẹ ba ara yi jẹ, ṣugbọn li ẹran ara mi li emi o ri Ọlọrun: ẹniti emi o ri fu ara mi, ti oju mi yio sì ri, kì iṣe ti ẹlomiran. *Job* 19. 25, 26, 27.

AWA kò mu nkan wá si aiye yi, o sì daniloju pe, awa kò sì le mu nkan jade lọ. JEHOFA fifuni, JEHOFA sì gbà a lọ; ibukún li Orukọ JEHOFA. 1 *Tim.* 6. 7; *Job* 1. 21.

PSALMU 39.

MO ni, Emi o ma kiye si ọ̀na mi, ki emi ki o má fi ahọn mi ṣẹ̀: emi o fi ijanu ko ara mi li ẹnu, nigbati enia buburu ba mbẹ niwaju mi.

Mo fi idakẹ yadi, mo tilẹ pa ẹnu mi mọ́ kuro li ọ̀rọ rere; ibinujẹ mi sì ru soke.

Digitized by Google

Àiya mi gbona ninu mi, nigbati emi sì nronu, iná ràn: nigba na ni mo fi ahọn mi sòrọ.

Jehofa jẹ ki emi ki o mọ opin mi, ati iwọn ọjọ mi bi o ti ri; ki emi ki o le mọ igba ti mo ni nihin.

Kiye si i, iwọ ti sọ ọjọ mi dabi ibú atẹlẹwọ: ọjọ ori mi sì dabi asan niwaju rẹ: nitõtọ olukuluku enia ninu ijoko rere rẹ̀ asan ni patapata.

Nitõtọ li aworan asan li enia gbogbo nrìn: nitõtọ ni nwọn nyọ ara wọn lẹnu li asan: o nkó ọrọ̀ jọ, kò sì mọ̀ ẹniti yio kó wọn lọ.

Njẹ nisisiyi, Oluwa, kini mo duro dè? ireti mi mbẹ li ọdọ rẹ.

Gbà mi ninu irekọja mi gbogbo: ki o má sì sọ mi di ẹ̀gan ti awọn enia buburu.

Mo yadi, emi kò ya ẹnu mi; nitori pe iwọ li o ṣe e.

Mu ọwọ́ ìna rẹ kuro lara mi: emi ṣegbé tan nipa ìja ọwọ́ rẹ.

Nigbati iwọ ba fi ibawi kìlọ fu enia nitori ẹ̀ṣẹ̀, iwọ a ṣe ẹwà rẹ̀ aparun bi kòkoro aṣọ: nitõtọ asan li enia gbogbo.

Jehofa, gbọ́ adura mi, ki o sì fi etí si ẹkún mi; ki o má ṣe pa ẹnu rẹ mọ́ si omije mi: nitori alejò li emi lọdọ rẹ, ati atipo, bi gbogbo awọn babba mi ti ri.

Da mi si, ki emi li agbara, ki emi ki o to kuro nihinyi lọ, ati ki emi ki o to ṣe alaìsi.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí Mimọ́.

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẽni yio sì ma ri nigba-gbogbo: aiye alnipẹkun. Amin.

Digitized by Google

ISINKÚ.

Psalmu 90.

JEHOFA, iwọ li o ti nṣe ibujoko wa lati irandiran.

Ki a to bí awọn òke nla, ati ki iwọ ki o to da ilẹ on aiye, ani lati aiye-raiye, iwọ li Ọlọrun.

Iwọ sọ enia di ibajẹ; iwọ sì wipe, Ẹ tún pada wá, ẹnyin awọn ọmmọ enia.

Nitori pe igbati ẹgbẹrun ọdún ba kọja li oju rẹ bi aná li o ri, ati bi igba iṣọ́ kan li oru.

Iwọ nkó wọn lọ bi ẹnipe ni ṣiṣan omi; nwọn dabi orun: ni kutukutu nwọn dabi koriko ti o dàgba soke.

Ni kutukutu o li àwọ lara, o sì dàgba soke; li aṣalẹ a ke e lulẹ, o sì rọ.

Nitori awa di egbé nipa ibinu rẹ, ati nipa ibinu rẹ ara kò rọ̀ wa.

Iwọ ti gbé èṣẹ wa kalẹ niwaju rẹ, èṣẹ ìkọkọ wa mbẹ ninu imọlẹ iwaju rẹ.

Nitori ti ọjọ wa gbogbo nyipo lọ ninu ibinu rẹ: awa nlò ọjọ wa bi alá ti a nrò.

Ãdọrin ọdún li ọjọ awọn ọdún wa; bi o sì ṣepe nipa ti agbara bi nwọn ba tó ọgọrin ọdún, agbara wọn lãlã on ibinujẹ ni; nitori nisisiyi ni yio ke kuro, awa a sì fò lọ.

Tali o mọ agbara ibinu rẹ? gẹgẹ bi èru rẹ, bẹ̀ni ibinu rẹ.

Bẹ̀ni ki iwọ ki o kọ́ wa lati ma kaye ọjọ wa, ki awa ki o le fi ọkkàn wa sipa ọgbọ́n.

Pada, Jehofa, yio ti pẹ to? ronupiwada nitori ti awọn ọmmọ ọdọ rẹ.

Fi ãnu rẹ tẹ́ wa li ọrùn ni kutukutu; ki awa ki o le ma yọ̀, ati ki inu wa ki o le ma dùn li ọjọ wa gbogbo.

Mu inu wa dùn bi iye ọjọ ti iwọ pọ́n wa loju, ati iye ọdún ti awa ti nri buburu.

Digitized by Google

Jẹ ki iṣẹ rẹ ki o hàn si awọn ọmmọ ọdọ rẹ, ati ogo rẹ si awọn ọmmọ wọn.

Jẹ ki ẹwà ti Jehofa Ọlọrun wa ki o sì mbẹ lara wa: ki iwọ ki o sì fi idi iṣẹ ọwọ́ wa mulẹ lara wa; bẹ̃ni iṣẹ ọwọ́ wa ni ki iwọ ki o fi idi rẹ mulẹ.

Ogo ni fu Babba, ati fu Ọmmọ: ati fu Ẹmmí mimọ́.

Bi o ti wà li àtetekọṣe, mbẹ nisisiyi, bẹ̃ni yio sì ma ri nigba-gbogbo: aiye alnipẹkun. Amin.

1 Kor. 15. 20.

NJẸ nisisiyi Kristi ti jinde kuro ninu okú, o sì di akọbi ninu awọn ẹniti o sùn. Nitori igbati o ti ṣepe lati ipa ọdọ enia ni ikú ti wá, nipa ọdọ enia li ajinde ninu okú sì ti wá pẹlu. Nitori bi gbogbo enia ti kú nipa ti Adamu, bẹ̃ni gbogbo enia yio sì di ãye nipa Kristi. Ṣugbọn olukuluku enia ni ipa ti rẹ̀: Kristi akọbi; lẹhin eyi-ni awọn ti ṣe ti Kristi li àbọ rẹ̀. Nigbana li opin yio de, nigbati yio ti fi ijọba fu Ọlọrun, ani Babba tikara rẹ̀; nigbati o ba ti tẹri gbogbo awọn olori, ati gbogbo ọlá ati agbara ba. Nitori pe, kò le ṣe alma jọba titi yio fi tẹ̀ ori gbogbo awọn ọtá mọlẹ li atẹlẹsẹ rẹ̀. Ikú li ọtá ti yio parun kẹhin. Nitori o ti tẹ̀ ohun gbogbo mọlẹ li atẹlẹsẹ rẹ̀. Ṣugbọn nigbati o wipe, ohun gbogbo li a fi si abbẹ rẹ̀, o daniloju pe, on nikanṣoṣo li o kù, ti o fi ohun gbogbo si i labbẹ. Nigbati a ba sì tẹri ohun gbogbo ba fu u tan, nigbana li Ọmmọkọnri tikara rẹ̀ pẹlu yio tẹriba fu ẹniti o fi ohun gbogbo si abbẹ rẹ̀, ki Ọlọrun ki o le jasi gbogbo li ohun gbogbo. Njẹ kili awọn ti a baptisi nitori awọn okú yio ha ṣe, bi o ba ṣepe awọn okú kò jinde rara?

Digitized by Google

nitori kili a ha ṣe mbaptisi wọn nitori awọn okú? Nitori kili awa sì ṣe mbẹ ninu ewu ni wakati gbogbo? Ayọ nyin ti mo ni nipa Kristi Jesu Oluwa wa ni mo fi sọ pe, emi nkú li ojojumọ. Ki a wi nipa ti enia, bi mo ba ẹranko jà li Efesu, anfani kili o ṣe fu mi, bi o ba ṣepe awọn okú kò jinde? ẹ jẹ ki a ma jẹ, ẹ jẹ ki a ma mu, ọla li awa o sá kú. Ki a má tàn nyin jẹ: idapọ buburu o ba ìwa rere jẹ. Ẹ jí si ododo, ki ẹ má sì dẹṣẹ mọ; nitori awọn diẹ kò ni ìmọ Ọlọrun: mo sọ eyi fu itiju nyin. Ṣugbọn ẹlomiran yio wipe, Bawo li a o ha jí awọn okú dide? ara bawo ni nwọn o pada si? Iwọ alaìmoye, irú ohun ti iwọ fọnrugbin kò hù, bikoṣepe o ba kú: Ati eyi ti iwọ fọnrugbin, ara ti mbọ ki iwọ fọnrugbin, ṣugbọn ọmmọ ni iso, iba ṣe alikama, tabi irú omiran: Ṣugbọn Ọlọrun fu u li ara bi o ti wù u, ati fu irú olukuluku ara ti rẹ. Gbogbo ẹran ara kì iṣe ẹran ara kan na; ṣugbọn ọtọ li ẹran ara ti enia, ọtọ li ẹran ara ti ẹranko, ọtọ ni ti ẹja, ọtọ sì ni ti ẹiyẹ. Ara ti oke ọrun mbẹ, ara ti aiye sì mbẹ; ṣugbọn ogo ti oke ọrun ọtọ, ati ogo ti aiye ọtọ. Ọtọ li ogo ti õrùn, ọtọ li ogo ti oṣupa, ọtọ sì li ogo ti ìrawọ; ìrawọ ekini sá yàtọ si ekeji li ogo. Gẹgẹ bẽ sì li ajinde ti awọn okú. A gbìn i ni idibajẹ; a sì jí i dide li aìdibajẹ: A gbìn i li aìniyìn; a sì jí i dide li ogo: a gbìn i li aìlera; a sì jí i dide li agbara: A gbìn i li ara iyara; a jí i dide li ara ẹmmí. Ara iyara mbẹ, ara ẹmmí sì mbẹ. Bẽli a sì kọ ọ pe, Adamu iṣaju ọkọnri alãye ọkkàn li a da a; Adamu ikẹhin ẹmmí asọnidãye. Ṣugbọn eyi ti ṣe ẹlẹmmí kò tète ṣaju, bikoṣe eyi ti ṣe ara iyara; nikẹhin eyi ti ṣe ẹlẹmmí. Ọkọnri iṣaju ati inu erupẹ wá, elerupẹ: ọkọnri ekeji li Olu-

Digitized by Google

wa lati ọrun wá. Bi elerupẹ ti ri, bẹ̃ sì ni irú awọn ti ṣe elerupẹ : bi ẹniti ṣe tọrun ti ri, bẹ̃ sì ni irú awọn ti ṣe tọrun. Bi awa sì ti rù aworan elerupẹ, bẹ̃li awa o sì rù aworan ti ṣe tọrun. Arakọnri, njẹ eyi ni mo wi fu nyin, pe ẹran ara on ẹjẹ kò le jogún ijọba Ọlọrun; bẹ̃ni idibajẹ kò le jogún aìdibajẹ. Kiye si i, òrọ ijinlẹ ni mo fi hàn nyin; Gbogbo wa kì yio sùn, ṣugbọn gbogbo wa li a o pa lara da, Lógan, ni iṣẹju kan, nigba ìpe ikẹhin : nitori ti ìpe yio dún, a o sì jí awọn okú dide li aìdibajẹ, a o sì pa wa lara da. Nitori pe ara idibajẹ yi, yio mu aìdibajẹ wọ̀, ati ara ikú yi yio mu aìkú wọ̀. Nigbati ara idibajẹ yi ba ti mu aìdibajẹ wọ̀, ti ara ikú yi ba sì ti mu aìkú wọ̀ bẹ̃ tan, nigba na li òrọ ti a kọ yio ṣẹ pe, A gbé ikú mì ni iṣẹgun. Ikú oró itani rẹ wà ? Isà okú iṣẹgun rẹ wà ? Oró itani ikú li ẹṣẹ ; ati agbara ẹṣẹ li ofin. Ṣugbọn ọpẹ ni fu Ọlọrun, ẹniti o ti fi iṣẹgun fu wa nipa Jesu Kristi Oluwa wa. Nitori na, ẹnyin arakọnri mi olufẹ, ẹ ma duro ṣinṣin, li alyẹsẹ, ki ẹnyin ki o ma pọ̀ si i ni iṣẹ́ Oluwa nigba-gbogbo, niwọnbi ẹnyin ti mọ̀ pe iṣẹ́ nyin kì iṣe asan nipa ti Oluwa.

Nigbati a o ba tẹ̀ okú si isà.

Alufa o wipe.

ENIA ti a bí ninu obiri ọjọ kukuru ṣá li o ni gbé li aiye, o sì kún fu òṣi. O ndàgba soke, a sì ke e lulẹ, bi itana eweko ; ọ fò lọ bi ojiji, lai kò sì duro ni ibi kan.

Li arin ìye awa mbẹ ninu ikú : lọdọ tali awa o ha ma wá àbo, bikoṣe lọdọ rẹ, Oluwa, ẹniti o ti itori ẹṣẹ wa jare ati binujẹ ?

Digitized by Google

Ṣugbọn, Oluwa Ọlọrun mimọ́ julọ, Oluwa alagbara julọ, Olugbala ẹni mimọ́ ati alãnu julọ, má fi wa sinu irora korò ti ikú ti kò nipẹkun.

Oluwa, iwọ mọ́ ohun ìkọkọ ọkàn wa; má ṣe di etí ãnu rẹ si adura ti wa; ṣugbọn Oluwa mimọ́ julọ, Ọlọrun alagbara julọ, Olugbala mimọ́ ati alãnu julọ, da wa si, titi lai iwọ ti o yẹ julọ li Onidajọ, li opin wakati wa, nitori irora-kirora ikú, má jẹ ki a ṣubu kuro lọdọ rẹ.

Nigbati a o ba bu erupẹ si okú lori.

Alufa o wipe.

NJẸ bi o ti wù Ọlọrun Olodumare ninu ãnu rẹ nla, lati gbà ọkàn arakọnri wa yi ọwọn, ti o fi ihin silẹ lọ sọdọ ara rẹ, nitori na awa fi ara rẹ fu ilẹ; erupè fu erupè, ẽru fu ẽru, ekuru fu ekuru; ni idaniloju ati li alṣiyemeji ireti ti Ajinde si ìye ti kò nipẹkun, nitori Jesu Kristi Oluwa wa; ẹniti yio pa ara òṣi wa da, ki o le ri bi ara on tikara rẹ ti o li ogo, gẹgẹ bi iṣẹ agbara, nipa eyi ti on le fi ṣẹgun ohun gbogbo fu ara rẹ.

Nigbana li Alufa o wipe.

MO gbọ́ ohùn kan lati ọrun wá, o nwi fu mi pe, Kọwe rẹ, Lati ihinlọ, ibukún ni fu awọn okú ti o kú nipa ti Oluwa: bẹ̃ li Ẹmmí wi; nitori ti nwọn simi ninu lãlã wọn.

Oluwa, ṣãnu fu wa.
Kristi, ṣãnu fu wa.
Oluwa, ṣãnu fu wa.

Digitized by Google

ISINKÚ.

BABBA wa ti mbẹ li ọrun, Ọwọ li orukọ rẹ. Ijọbba rẹ de. Ifẹ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, Bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ojọ wa loni. Dari ẹṣẹ wa jì wa, Bi a ti ndari ẹṣẹ jì awọn ti o ṣẹ wa. Má fà wa sinu idẹwò; Ṣugbọn gbà wa ninu tulasin. Amin.

Alufa.

OLỌRUN Olodumare, ẹniti ẹmmí awọn ẹniti o fi ihin silẹ lọ nipa ti Oluwa, mbẹ lọdọ rẹ, ati lọdọ ẹniti ọkkàn ti awọn onigbagbọ́, lẹhin igbati a yọ wọn kuro ninu ẹrù ẹran ara wọn, mbẹ ninu ayọ̀ on irọra; Tọkkàntọkkàn li awa fi ndupẹ fu ọ, nitori ti o wù ọ lati yọ arakọnri wa yi kuro ninú òṣi aiye yi ti o kún fu ẹṣẹ; awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki o le wù ọ, nitori ore ifẹ inu rere rẹ, li alpẹ titi ki o to pari iye awọn ayanfẹ rẹ, ati ki o mu ijọbba rẹ yara wá; ki awa, pẹlu gbogbo awọn ti o fi ihin silẹ lọ ni igbagbọ́ otitọ ti Orukọ rẹ mimọ́, ki awa ki a le ni ẹkún ati irọra wa anidopin, ati li ara ati li ọkkàn titi lai ninu ogo rẹ ti kò nipẹkun; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

ADURA.

OLỌRUN Alãnu, Babba Jesu Kristi Oluwa wa, ẹniti ṣe ajinde ati ìye; ẹnikẹni ti o gbagbọ́ ninu ẹniti yio wà lãye, bi o tilẹ kú; ati ẹnikẹni ti o wà lãye, ti o sì gbà a gbọ́, ki yio kú titi lai; ẹniti o sì ti ọwọ́ Paulu Aposteli rẹ mimọ́ kọ wa pe, ki a má binujẹ bi awọn ti kò ni ireti, fu awọn ti o sùn nipa ti on; Awa nfi ọkkàn tutù bẹbẹ lọdọ rẹ, Babba, ki o jí wa

Digitized by Google

dide kuro ninu ikú ẹ̀ṣẹ́ si ìye ododo; nigbati awa o ba fi aiye yi silẹ lọ, ki awa ki o le simi lọdọ rẹ̀, bi ireti wa ti ri, bẹ̃ni ti arakọnri wa yi jasi; ati li Ajinde gbogbo enia li opin ọjọ́, ki a le ba wa li ẹni atẹwọgba li oju rẹ; ki a sì le ri ibukún na gbà, ti Ọmmọ rẹ olufẹ jọ̀jọ́ yio sọ nigbana fu gbogbo awọn ti o fẹ ẹ ti nwọn sì bẹ̀ru rẹ, wipe, Wá ẹnyin alabukún-fu ọmmọ ti Babba mi, ẹ gbà ijọba ti a ti pèse silẹ fu nyin lati ipilẹṣẹ ọjọ́ wá: Fi eyi fu ni, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, Babba alãnu, nitori Jesu Kristi, Onilaja ati Oludande wa. *Amin.*

2 Kor. 13. 14.

ORE-ỌFẸ Jesu Kristi Oluwa wa, ati ifẹ Ọlọrun, ati idapọ ti Ẹmmí Mimọ́, ki o ma ba gbogbo wa gbé si i lailai. *Amin.*

Digitized by Google

IDUPẸ AWỌN OBIRI LẸHIN IBIMỌ.

¶ *Nigbana li Alufa yio dahùn wi fu u pe,*

NIWỌN-BI o ti wu Ọlọrun Olodumare ninu õre rẹ lati da ọ silẹ li alafia, ti o sì ti dãbò bò ọ ninu ewu nla ti bíbi ọmmọ; nitorina ki iwọ ki o fi tọkkàntọkkàn dupẹ fu Ọlọrun, ki o sì wipe,

¶ (*Nigbana ni Alufa yio kà Psalmu* 116.)

MO fẹ Jehofa nitori ti o ti gbohùn mi, ati ẹbẹ mi.

Nitori ti o dẹti rẹ si mi, nitorina li emi o ṣe ma ke pè e niwọn ọjọ mi.

Ikãnu ikú yi mi ka, ati irora isà oku dì mi mu; mo ri iyọnu ati ikãnu.

Nigbana ni mo pè orukọ Jehofa; Jehofa, emi bè ọ, gbà ọkkàn mi.

Olore ọfẹ li Jehofa ati Olododo; nitõtọ, alãnu li Ọlọrun wa.

Jehofa pa awọn òpe mọ́: a rẹ mi silẹ tan, o sì ràn mi lọwọ́.

Pada sibi isimi rẹ, iwọ ọkkàn mi; nitori ti Jehofa ṣe ọpọlọpọ fu ọ.

Nitori ti iwọ gbà ọkkàn mi lọwọ́ ikú, oju mi lọwọ́ omije, ati ẹsẹ mi lọwọ́ iṣubu.

Emi o ma rìn niwaju Jehofa ni ilẹ alãye.

Emi gbagbọ́, nitorina li emi ṣe sọ; mo ri ipọnju gidigidi.

Mo wi ni iyara mi pe, eke ni gbogbo enia.

Ki li emi o fi fu Jehofa nitori gbogbo ore rẹ si mi?

Digitized by Google

Emi o mu ago igbala, emi o sì ma ke pè orukọ Jehofa.

Emi o san ileri ifẹ́ mi fu Jehofa nisisiyi li oju awọn enia rẹ̀ gbogbo.

Iyebiye ni iku awọn enia mimọ rẹ̀ li oju Jehofa.

Jehofa nitõtọ, iranṣẹ rẹ li emi; iranṣẹ rẹ li emi, ọmmọ iranṣẹ biri rẹ; iwọ ti tú idè mi.

Emi o ru ẹbọ ọpẹ́ si ọ emi o ma pè orukọ Jehofa.

Emi o san ileri ifẹ́ mi fu Jehofa nisisiyi niwaju gbogbo awọn enia mimọ rẹ̀.

Ninu àgbala ile Jehofa, larin rẹ, iwọ Jerusalẹmu, Ẹ yin Jehofa.

Tabi Psalm 127.

BIKOṢEPE Jehofa ba kọle na awọn ti nkọ ọ nṣiṣẹ́ lasan: bikoṣepe Jehofa ba pa ilunla na mọ́, oluṣọ ji lasan.

Asan ni fu ọ lati dide ni kutukutu, lati joko di àjiji lati jẹun ikãnu: bẹ̃ni o nfi õrun fu olufẹ rẹ̀.

Kiye si i awọn ọmmọ ni ini Jehofa: ọmmọ inu sì li ère rè.

Bi ọfà ti ri lọwọ́ alagbara, bẹ̃li awọn ọmmọ ewe.

Ibukún ni fu ọkọnri na ti apó rẹ̀ kún fu wọn: oju kì yio tì wọn, ṣugbọn nwọn o ṣẹgun awọn ọtá li ẹnu ọ̀na.

¶ *Nigbana ni alufa yio wipe,*

Ẹ jẹ ki agbadura.

Oluwa ṣãnu fu wa.
Kristi ṣãnu fu wa.
Oluwa ṣãnu fu wa.

Digitized by Google

IDUPẸ AWỌN OBIRI LẸHIN IBIMỌ.

BABBA wa ti mbẹ li ọrun; Ọwọ li orukọ rẹ. Ijọbba rẹ de. Ifẹ ti rẹ ni ki a ṣe li aiye, bi nwọn ti nṣe li ọrun. Fu wa li onjẹ ojọ wa loni. Dari ẹṣẹ wa jì wa, bi ati ndari ẹṣẹ jì awọn ti o ṣẹ wa. Má fà wa sinu idẹwo; ṣugbọn gbà wa ninu tulasìn. Nitori Ijọbba ni ti rẹ, agbara ni ti rẹ, ogo ni ti re; lailai. Amin.

Alufa. Oluwa, gbà obiri yi iranṣẹ rẹ là;

Idahùn. Eniti o gbẹkẹ rẹ le ọ.

Alufa. Ki iwọ ki o jẹ ile iṣọ alagbara fu u;

Idahùn. Li oju awọn ọta rẹ.

Alufa. Oluwa, gbọ́ adura wa.

Idahùn. Ki o sì jẹ ki igbe wa ki o wa si ọdọ rẹ.

Alufa. Jẹ ki agbadura.

OLỌRUN Olodumare, awa nfi irẹlẹ dupẹ fu ọ, nitori ti o wù ọ lati gbà obiri yi iranṣẹ rẹ, ninu irora nla ati ewu ti Bíbi-Ọmmọ; Fifu ni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, Babba alãnu julọ, ki on, nipa iranlọwọ rẹ, ki o le wà, ki o sì le rìn li ododo gẹgẹ bi ifẹ rẹ li aiye isisiyi; ati pẹlu ki o le jẹ alabapin ogo ti kò nipẹkun ni iyè aiye tì mbọ̀ wa; nitori Jesu Kristi Oluwa wa. *Amin.*

Digitized by Google

IWE TI AWỌN PSALMU.

OWURỌ IJỌ. I.

Psalmu 1.

IBUKÚN ni fu ọkọnri na ti kò rìn ni ìmọ ti awọn enia buburu, ti kò duro li ọ̀na ti awọn ẹlẹṣẹ, ati ti kò sì joko ni ibujoko ti awọn ẹlẹgàn.

2 Ṣugbọn didùn-inu rẹ̀ wà li ofin Jehofa; ati ninu ofin rẹ̀ ni nṣe aṣaro li ọsán ati li oru.

3 Yio sì dabi igi ti a gbìn si etí ipa odò omi, ti o nso eso rẹ̀ jade li akokò rẹ̀; ewé rẹ̀ kì yio sì rẹ̀; ati ohun-kohun ti o ṣe ni yio ma ṣe dede.

4 Awọn enia buburu kò ri bẽ : ṣugbọn nwọn dabi ìyangbo ti afẹfẹ nfẹ lọ.

5 Nitorina awọn enia buburu kì yio le duro ni idajọ, bẽli awọn ẹlẹṣẹ kì yio le duro li awujọ ti awọn olododo.

6 Nitori ti Jehofa mọ̀ ọ̀na ti awọn olododo : ṣugbọn ọ̀na ti awọn enia buburu ni yio ṣegbé.

Psalmu 2.

ẼṢE ti awọn keferi fi irọkẹkẹ pejọ pọ̀, ati ti awọn enia ngbìro ohun asan?

2 Awọn ọbba aiye kẹṣẹ jọ, ati awọn ijoye

Digitized by Google

ngbìmọ pọ̀, si JEHOFA, ati si ẹni atorórosi rẹ̀, wipe,

3 Ẹ jẹ ki a fà ìde wọn já, ki a sì mu okùn wọn kuro lọdọ wa.

4 Ẹniti o joko li ọrun yio rerin : OLUWA yio yọ sùti si wọn.

5 Nigbana ni yio sọ̀rọ si wọn ni ibinu rẹ̀, yio sì tọ́ wọn ninu ibinujẹ rẹ̀ kikan.

6 Ṣugbọn mo ti fi oróro pa Ọbba mi lori Sion òke mimọ́ mi.

7 Emi o sì pa a laṣẹ : JEHOFA ti wi fu mi pe, Iwọ li Ọmmọkọnri mi ; loni ni mo bí ọ.

8 Bère lọwọ́ mi, emi o sì fi awọn keferi fu ọ ni ini rẹ, ati ìha opin ti ilẹ li ọrọ̀-ilẹ rẹ.

9 Ọpá irin ni iwọ o fi fọ́ wọn; iwọ o sì rún wọn womu-womu, bi ohun èlo amọ̀.

10 Njẹ nitorina ki ẹnyin ki o gbọ́n, ẹnyin ọbba : ki a sì kọ́ nyin, ẹnyin onidajọ ti aiye.

11. Ẹ fi ìbẹ̀ru sìn JEHOFA, ẹ sì ma yọ̀ ti ẹnyin ti iwa-rìri.

12 Fi ẹnu kò Ọmmọkọnri na lẹnu, ki o máṣe binu, ẹnyin a sì ṣegbé kuro loju ọ̀na, nigbati inu rẹ̀ ba ru diẹ kiun. Ibukún ni fu gbogbo awọn ti o gbẹ̀kẹ̀ wọn le e.

PSALMU 3.

JEHOFA, awọn ti nyọ mi lẹnu ti npọ̀ to yi? ọ̀pọ̀lọpọ̀ li awọn ti o dide si mi.

2 Ọpọ̀lọpọ̀ li awọn ti o nwi niti ọkkàn mi pe, Iranlọwọ kò si fu u nipa ti Ọlọrun.

3 Ṣugbọn iwọ, JEHOFA, li asà fu mi ; ogo mi, ati olugbé ori mi soke.

4 Emi fi ohùn mi kigbe si JEHOFA, o sì gbohùn mi lati òke mimọ́ rẹ̀ wá.

5 Emi dubulẹ, mo sì sùn ; mo sì jí ; nitori ti JEHOFA tì mi lẹhin.

Digitized by Google

6 Emi kì yio bèru ẹgbarun enia, ti nwọn rọ̀gba yi mi ká.
7 Dide, JEHOFA; gbà mi, Ọlọrun mi: nitori iwọ li o lù gbogbo awọn ọtá mi li egungun ẹrẹkẹ; iwọ sì ká ehin ti awọn enia buburu.
8 Ti JEHOFA ni igbala: ibukún rẹ sì mbẹ lara awọn enia rẹ.

PSALMU 4.

GBOHÙN mi nigbati mo ba npè, Ọlọrun ododo mi: iwọ li o da mi ni ide ninu ipọnju; ṣe oju rere fu mi, ki o sì gbọ́ adura mi.
2 Ẹnyin ọmmọkọnri enia, ẹ o ti sọ ogo mi di itiju pẹ to? ẹnyin o ti fẹ asan pẹ to, ti ẹ o sì ma wá idalẹ kiri?
3 Ṣugbọn ki ẹ mọ̀ pe JEHOFA ti yà ẹni ìwa-bi-ọlọrun sọ̀tọ fu ara rẹ̀: JEHOFA yio gbọ́ nigbati mo ba kepè e.
4 Ẹ duro ninu èru, ẹ má sì ṣe ṣẹ̀: ẹ ba ọkkàn nyin sọ̀rọ lori ẹní nyin, ki ẹ sì duro jẹ.
5 Ẹ ru ẹbọ ododo, ki ẹ sì gbẹkẹ nyin le JEHOFA.
6 Ẹni pupọ̀ li o nwipe, Tani yio ṣe rere fu wa? JEHOFA, iwọ gbé imọlẹ oju rẹ soke si wa lara.
7 Iwọ ti fi ayọ̀ si mi li ọkkàn, jù igba na lọ ti ọkà wọn ati ọti wain wọn di pupọ̀.
8 Emi o sì dubulẹ pẹlu li alafia, emi o sùn: nitori iwọ, JEHOFA, nikanṣoṣo li o nmu mi joko li alàlewu.

PSALMU 5.

FI etí si ọ̀rọ mi, JEHOFA, rò iṣaro mi.

Digitized by Google

2 Fi etí si ohùn ẹkún mi, Ọbba mi, ati Ọlọrun mi : nitori pe ọdọ rẹ li emi o ma gbadura si.

3 Ohùn mi ni iwọ o gbọ́ li owurọ̀, JEHOFA ; li owurọ̀ li emi o gbà adura mi si ọ, emi o sì ma wòke.

4 Nitori ti iwọ kì iṣe Ọlọrun ti ṣe inudidùn si ìwa buburu : bẹ̃ni buru kò le ba o gbé.

5 Awọn enia gberaga kì yio duro niwaju rẹ: iwọ korira gbogbo awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ.

6 Iwọ o pa awọn ti nsọ idalẹ run: JEHOFA yio korira awọn ẹni ẹ̀jẹ ati ẹni ẹ̀tan.

7 Ṣugbọn bi o ṣe ti emi, emi o wá sinu ile rẹ li ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ; ninu ẹ̀ru rẹ li emi o gbadura si tempeli mimọ́ rẹ.

8 Tọ́ mi, JEHOFA, ninu ododo rẹ, nitori awọn ọtá mi : mu ọ̀na rẹ tọ́ tàra ni iwaju mi.

9 Nitori ti otitọ kan kò si li ẹnu wọn ; ika-kika ni iha inu wọn : isa-okú ti o ṣí silẹ li ọfọn wọn; ahọn wọn-ni nwọn fi npọ́n-ni.

10 Iwọ da wọn lẹbi, Ọlọrun ; ki nwọn ki o ti ipa ìmọ ara wọn ṣubu ; já wọn kuro ninu ọ̀pọlọpọ irekọja wọn ; nitori ti nwọn ti ṣọ̀tẹ si ọ.

11 Ṣugbọn jẹ ki gbogbo awọn ti o gbẹ̀kẹle ọ ki o yọ̀ ; lai ki nwọn ki o ma hó fu ayọ̀, nitori ti iwọ dãbobo wọn : jẹ ki awọn ti o fẹ orukọ rẹ pẹlu ki nwọn ki o ma yọ̀ nipa rẹ.

12 Nitori ti iwọ, JEHOFA, ni yio bukún u fu olododo ; oju-rere ni iwọ o fi yi i ká bi asà.

Digitized by Google

ALẸ IJỌ. 1.

PSALMU 6.

JEHỌFA, má ṣe ba mi wi ni ibinu rẹ, ki iwọ ki o má ṣe nà mi ni gbigbona ibinujẹ rẹ.

2 JEHOFA, sãnu fu mi; nitori àllera mi: JEHOFA, mu mi lara da; nitori ti ara kan egungun mi.

3 Ara kan ọkkàn mi gogo pẹlu: ṣugbọn iwọ, JEHOFA, yio ti pẹ to?

4 Pada, JEHOFA, gbà ọkkàn mi là: gbà mi là nitori ãnu rẹ.

5 Nitori ti kò si iranti rẹ ninu okú: ninu isa-okú tani yio dupẹ fu ọ?

6 Agara ikerora mi da mi; li oru gbogbo li emi nmu ẹní mi fò li oju omi; emi fi omije rin ibùsun mi.

7 Oju mi bajẹ tan nitori ibinujẹ; o di ogbó tan nitori gbogbo awọn ọtá mi.

8 Ẹ lọ kuro lọdọ mi, gbogbo ẹnyin onișẹ ẹṣẹ; nitori ti JEHOFA gbọ́ ohùn ẹkún mi.

9 JEHOFA gbọ́ ẹbẹ mi; JEHOFA yio gbà adura mi.

10 Jẹ ki oju ki o tì gbogbo awọn ọtá mi, ki ara ki o kan wọn gogo: jẹ ki nwọn ki o pada ki oju ki o tì wọn li ojijì.

PSALMU 7.

JEHOFA, Ọlọrun mi, iwọ ni mo gbẹkẹ mi le: gbà mi lọwọ́ gbogbo awọn ti nṣe inunibini si mi, ki o sì yọ mi kuro.

2 Ki o má ba fà ọkkàn mi ya bi kiniu, a ya a pẹrẹpẹrẹ, nigbati kò si olugbala.

Digitized by Google

3 Jehofa, Ọlọrun mi, bi mo ba ṣe eyi; bi ẹ̀ṣẹ̀ ba mbẹ̀ li ọwọ́ mi;
4 Bi mo ba fi ibi san a fu ẹniti emi ti rẹ̀ wà li alafia; (nitõtọ ẹniti nṣe ọtá mi li alnidi, emi tilẹ̀ gbà a là:)
5 Jẹ ki ọtá na ki o ṣe inunibini si ọkàn mi, ki o sì mu u; ki o tẹ̀ ẹmmí mi mọlẹ̀, ki o sì fi ọllá mi le inu ekuru.
6 Dide, Jehofa, ni ibinu rẹ̀, gbé ara rẹ̀ soke nitori ti ikanu awọn ọtá mi: ki iwọ ki o sì jí fu mi si idajọ́ ti iwọ ti pa li aṣẹ̀.
7 Bẽni ijọ awọn enia yio yi ọ ká kiri; njẹ nitori ti wọn iwọ pada si oke.
8 Jehofa yio ṣe idajọ́ awọn enia: Jehofa, ṣe idajọ́ mi, gẹ̀gẹ̀ bi ododo mi, ati gẹ̀gẹ̀ bi ìwatitọ inu mi.
9 Jẹ ki ìwa buburu ti awọn enia buburu ki o de opin; ṣugbọn mu ẹṣẹ̀ olotitọ duro: nitori ti Ọlọrun olododo li o ndan àiya ati inu wò.
10 Àbo mi mbẹ̀ lọdọ Ọlọrun, ti o nṣe igbala olotitọ li àiya.
11 Ọlọrun li onidajọ ododo, Ọlọrun sì nbinu si awọn enia buburu lojojumọ;
12 Bi on kò ba yipada, yio sì pọ́n idà rẹ̀ mu; o ti fà ọrun rẹ̀ le na, o ti mura rẹ̀ silẹ̀.
13 O sì ti pèse èlo ikú silẹ̀ fu u; o ti ṣe ìlana ọfà rẹ̀ silẹ̀ de awọn oninunibini.
14 Kiye si i, o nrọbi ẹ̀ṣẹ̀, o sì fi ìwa ìka lóyun, o sì bí eke jade.
15 O ti ṣe ọ̀fin, o wà a, o sì bọ́ sinu ihò ti on na wà.
16 Ìwa ìka rẹ̀ yio sì pada si ori ara rẹ̀, ati iṣẹ́ agbara rẹ̀ yio sì sọkalẹ̀ bọ̀ si atari ara rẹ̀.
17 Emi o yìn Jehofa gẹ̀gẹ̀ bi ododo rẹ̀: emi o sì kọrin iyìn si orukọ Jehofa Ọgá-ogo julọ.

Digitized by Google

PSALMU 8.

JEHOFA, Oluwa wa, orukọ rẹ ti ni iyìn to lori ilẹ aiye gbogbo! iwọ ti o gbé ogo rẹ kà rekọja ọrun.

2 Lati ẹnu awọn ọmmọ ọwọ, ati ọmmọ ọmu ni iwọ ti ṣe ìlana agbara, nitori awọn ọtá rẹ, nitori ki iwọ ki o le mu ọtá ati olugbẹsan ni dakẹjẹ.

3 Nigbati mo rò awọn ọrun rẹ, iṣẹ ika ọwọ rẹ, oṣupa ati irawọ, ti iwọ ti ṣe ìlana silẹ.

4 Kili enia, ti iwọ fi nṣe iranti rẹ? ati ọmmọkọnri enia, ti iwọ fi mbẹ ẹ wò?

5 Iwọ sá da a li onirẹlẹ diẹ jù awọn angeli lọ, iwọ sì ti fi ogo ati ọlá de e li ade.

6 Iwọ mu u jọbba iṣẹ ọwọ rẹ; iwọ sì fi ohun gbogbo sabbẹ ẹsẹ rẹ;

7 Awọn agutan ati awọn malu gbogbo, ati awọn ẹranko igbẹ pẹlu;

8 Awọn ẹiyẹ ti oju ọrun, ati awọn ẹja ninu okun, ati ohun-kohun ti o nkọja lọ nipa ọna okun.

9 JEHOFA, Oluwa wa, orukọ rẹ ti ni iyìn to lori ilẹ aiye gbogbo.

OWURỌ IJỌ. 2.

PSALMU 9.

EMI o yìn ọ, JEHOFA, ti gbogbo àiya mi; emi o fi gbogbo iṣẹ iyanu rẹ hàn.

2 Emi o yọ̀, emi o sì ṣe inu-didùn si ọ; emi o sì kọnrin iyìn si orukọ rẹ, iwọ Ọgá-ogo julọ.

3 Nigbati awọn ọtá mi ba pẹhinda, nwọn o ṣubu, nwọn o sì ṣegbé ni iwaju rẹ,

4 Nitori iwọ li o ti mu idajọ ati idi ọran

Digitized by Google

mi duro; iwọ li o joko lori itẹ ti o nṣe idajọ ododo.

5 Iwọ ba awọn keferi wi, iwọ pa awọn enia buburu run, iwọ pa orukọ wọn rẹ lai ati lailai.

6 Iwọ ọtá, iparun wọn-ni de opin lailai: iwọ li o sì ti run awọn ilu-nla; iranti wọn sì ti run pẹlu wọn.

7 Ṣugbọn JEHOFA yio wà titi lailai: o ti tẹ itẹ rẹ silẹ fu idajọ.

8 Yio sì ṣe idajọ aiye li ododo, yio ṣe idajọ fu awọn enia li otitọ lwa.

9 JEHOFA ni yio ṣe àbo awọn ẹni inilara, àbo ni igba ipọnju.

10 Awọn ti o sì mọ Orukọ rẹ nwọn o gbẹkẹ wọn le ọ: nitori iwọ, JEHOFA, kò ti kọ awọn ti nṣe afẹri rẹ silẹ.

11 Ẹ kọnrin iyìn si JEHOFA, ti o joko ni Sion: ẹ fi iṣẹ rẹ hàn ninu awọn enia.

12 Nigbati o nwadi ẹjọ ẹjẹ, o ranti wọn: on kò sì gbagbé ẹkún ti awọn olupọnju.

13 Ṣãnu fu mi, JEHOFA; rò iṣẹ ti emi nṣe lọwọ awọn ti o korira mi, iwọ ti o gbé ori mi soke kuro li ẹnu ọna ikú.

14 Ki emi ki o le ma fi gbogbo iyìn rẹ hàn li ẹnu ọna ti ọmmọbiri Sion: ẹmi o ma yọ ni igbala rẹ.

15 Awọn keferi jì sinu ọfin ti nwọn wà: ninu àwọn ti nwọn dẹ silẹ li ẹsẹ ara wọn kọ.

16 A mọ JEHOFA nipa idajọ ti o nṣe: iṣẹ ọwọ enia buburu li a fi ndẹkùn mu ara rẹ.

17 Ori awọn enia buburu li a o dà si ọrun apadi, ati gbogbo orilẹ ède ti o gbagbé Ọlọrun.

18 Nitori pe a kì yio gbagbé awọn alàìni nigba-gbogbo: abá ti awọn talakà kì yio ṣegbé lailai.

Digitized by Google

19 JEHOFA, dide; má ṣe jẹ ki enia ki o bori: jẹ ki a ṣe idajọ awọn keferi niwaju rẹ.
20 Dèru bà wọn, JEHOFA: ki awọn orilẹ ède ki o le mọ ara wọn pe enia ṣá ni wọn.

PSALMU 10.

ẼṢE ti iwọ fi duro li òkere rere, JEHOFA; ẽṣe ti iwọ fi fi ara pamọ ni igba ipọnju?
2 Ninu igberaga li enia buburu nṣe inunibini si awọn talakà: ninu arekereke ti nwọn ṣe ni ki a ti mu wọn.
3 Nitori ti enia buburu nṣe ileri ifẹ ọkkàn rẹ̀, ati oloju-kòkoro sì nsùre fu ara rẹ̀, o korira JEHOFA.
4 Enia buburu, nipa igberaga oju rẹ̀, kò fẹ ṣe afẹri Ọlọrun: Ọlọrun kò si ni gbogbo ìronu rẹ̀.
5 Buburu li ọna rẹ̀ nigba-gbogbo; idajọ rẹ fò oju rẹ̀ kọja rere; gbogbo awọn ọtá rẹ̀, li o nfẹ̀ si.
6 O ti wi li ọkkàn rẹ̀ pe, A kì yio ṣí mi ni ipò: lati iran-diran emi kì yio si ninu ipọnju.
7 Ẹnu rẹ̀ kún fu ebu, ati fu ètan, ati fu itanjẹ: ìwa ìka ati ìwa asan mbẹ labbẹ ahọn rẹ̀.
8 O joko ni buba ni iletò wọn-ni: ni ibi ìkọkọ wọn-ni li o npa awọn alaìṣẹ: o ti tẹjumọ awọn talakà nikòkọ.
9 O lumọ ni ibi ìkọkọ bi kiniu ninu ihò rẹ̀: o lumọ lati mu talakà: a sì mu talakà, nigbati o ba fà a sinu àwọn rẹ̀.
10 O bà, o rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ, ki talakà ki o le bọ si ipa ọwọ́ agbara rẹ̀.
11 O ti wi li ọkkàn rẹ̀ pe, Ọlọrun ti gbagbé: o pa oju rẹ̀ mọ; on kì yio ri i lailai.

Digitized by Google

12 Dide, Jehofa ; Ọlọrun, gbé ọwọ́ rẹ soke : má ṣe gbagbé olupọnju.

13 Êṣe ti enia buburu fi ngàn Ọlọrun ? o ti wi li ọkkàn rẹ pe, Iwọ kì yio bère rẹ.

14 Iwọ ti ri i ; nitori ti iwọ nwò ìwa ìka ati iwọsi, lati fi ọwọ́ ara rẹ bère rẹ ; talakà fi ara rẹ le ọ lọwọ́ ; iwọ li oluranlọwọ ti alaìnibabba.

15 Iwọ ṣẹ́ apa ti enia buburu, ati ti ọkọnri ibi ni : iwọ ṣe afẹri ìwa-buburu rẹ, titi iwọ kì yio fi ri nkan.

16 Jehofa li ọba lai ati lailai : awọn keferi parun kuro ni ilẹ rẹ.

17 Jehofa, iwọ ti gbọ́ ifẹ́ ti onirẹlẹ : iwọ o mu ọkkàn wọn duro, iwọ o mu etí rẹ gbọ́.

18 Lati ṣe idajọ́ alaìni-babba ati ẹni-inilara, ki ọkọnri aiye ki o máṣe daiya-fò-ni mọ́.

Psalmu 11.

JEHOFA ni mo gbẹkẹ mi le : ẹnyin ti ṣe wi fu ọkkàn mi pe, sá bi ẹ̀iyẹ lọ si òke nyin ?

2 Sá kiye si i, awọn enia buburu ti fà ọrun wọn le, nwọn ti fi ọfà sọ̀n li oju ọ̀sán, ki nwọn ki o le ta li òkunkun si ọlọkkàn diduro.

3 Bi ipilẹ ba baje kili olododo yio ṣe ?

4 Jehofa mbẹ ninu tempeli mimọ́ rẹ̀, itẹ́ Jehofa mbẹ li ọrun : oju rẹ̀ nwò, ipenpeju rẹ̀ ndan awọn ọmmọ enia wò.

5 Jehofa ndan olododo wò : ṣugbọn enia buburu ati ẹniti nfẹ ìwa agbara, ọkkàn rẹ̀ korira.

6 Lori enia buburu ni yio rọ̀jo ogun-ná ṣuṣu, iná ati sulfuru, ati ìji gbigbona : eyi ni yio ṣe òṣuwọn ago wọn.

Digitized by Google

7 Nitori ti JEHOFA olododo fẹ ododo; oju rẹ a sì ma wò ẹniti o duro ṣinṣin.

ALẸ IJỌ. 2.

PSALMU 12.

SE iranlọwọ, JEHOFA; nitori ti awọn ẹni ìwabi-Ọlọrun dasẹ; nitori ti awọn olõtọ dasẹ kuro ninu awọn ọmmọ enia.

2 Olukuluku wọn mba ẹnikeji rẹ sọ asan; ète ẹpọn ati ọkkàn meji ni nwọn fi nsọ.

3 JEHOFA yio ke gbogbo ète ipọn-ni kuro, ati ahọn ti nsòrọ ohùn nla:

4 Ẹniti o wipe, Ahọn wa li awa o fi ṣẹgun; ète wa ni ti awa: tani ṣe oluwa wa?

5 Nitori inira ti awọn talakà, nitori imí-èdọn ti awọn alaìni, JEHOFA wipe, nigbayi li emi o dide; emi o sì yọ ọ si ibi igbala, kuro lọwọ ẹniti nfẹ si i.

6 Òrọ ti JEHOFA òrọ mimọ́ ni; bi fadaka ti a dà ni ileru erupẹ, ti a dà ni igba meje.

7 Iwọ o pa wọn mọ́, JEHOFA, iwọ o pa olukuluku wọn mọ́ kuro lọwọ́ iran yi lailai.

8 Awọn enia buburu nrìn ni ìha gbogbo, nigbati a ba ngbé awọn enia-kenia leke.

PSALMU 13.

IWỌ o ti gbagbé mi pẹ to, JEHOFA? lailai? iwọ o ti pa oju rẹ mọ́ pẹ to kuro lara mi?

2 Emi o ti ma gbìmọ li ọkkàn mi pẹ to? ti emi o ma ni ibinujẹ li ọkkàn mi lojojumọ? ọtá mi yio ti gbéraga sori mi pẹ to?

3 Rò o ki o sì gbohùn mi, JEHOFA Ọlọrun mi: ṣí mi li oju, ki emi ki o má ba sùn ìsun ikú;

Digitized by Google

4 Ki ọtá mi ki o má ba wipe, emi ti ṣẹgun rẹ̀; awọn ti nyọ mi lẹnu a sì ma yọ̀ nigbati a ba ṣí mi nipò.
5 Ṣugbọn emi ti ngbẹkẹle ãnu rẹ; ọkkàn mi yio yọ̀ ni igbala rẹ.
6 Emi o ma kọrin si JEHOFA, nitori ti o ṣe fu mi li ọ̀pọlọpọ.

PSALMU 14.

ENIA buburu nwi li ọkkàn rẹ̀ pe, Ọlọrun kò si. Nwọn bajẹ, nwọn sì nṣe iṣẹ́ irira, kò si ẹni ti o ṣe rere.
2 JEHOFA bojuwò ilẹ lati ọrun wá sara awọn ọmmọ enia, lati wò bi ẹnikan wà ti oyé yé, ti o sì nwá Ọlọrun.
3 Gbogbo wọn li o sì yà si aparun, nwọn sì di elẽri patapata; kò si ẹni ti nṣe rere, kò si ẹnikan.
4 Gbogbo awọn ti nṣiṣẹ̀ èṣẹ kò ni ìmọ? awọn ẹniti njẹ enia mi bi ẹni jẹun, nwọn kò sì kepè JEHOFA.
5 Nibẹ̀ ni nwọn gbé wà ni ìbẹru nla: nitori ti Ọlọrun mbẹ ninu iran awọn olododo.
6 Ẹnyin ti dojutì ìmọ awọn talakà, nitori ti JEHOFA li àbo rẹ̀.
7 Tani yio fi igbala fu Israeli lati Sion jade wá! nigbati JEHOFA ba mu ikolọ ogun awọn enia rẹ̀ pada wá, Jakobu yio yọ̀, inu Israeli yio sì dùn.

OWURỌ̀ IJỌ. 3.

PSALMU 15.

JEHOFA, tani yio ma ṣe atipo ninu agọ́ rẹ? tani yio ma gbé inu òke mimọ́ rẹ?

Digitized by Google

2 Ẹniti o nrìn dede, ti nṣiṣẹ ododo, ti o sì nsọ otitọ lati ọkkàn rẹ wá.
3 Ẹniti kò fi ahọn rẹ sòrọ ẹni lẹhin, ti kò sì ṣe ibi si ẹnikeji rẹ, ti kò sì gbà òrọ ègan si ẹnikeji rẹ.
4 Li oju ẹniti enia-kenia di gigan; ṣugbọn a ma bu ọlá fu awọn ti o bèru JEHOFA. Ẹniti o bura si ibi ara rẹ, ti kò sì yipada.
5 Ẹniti kò fi owo rẹ gbà elé, ti kò sì gbà owo èbẹ si alaìṣẹ. Ẹniti o ba ṣe nkan wọnyi kì yio yẹṣẹ lailai.

PSALMU 16.

OLỌRUN, pa mi mọ: nitori iwọ ni mo gbẹkẹ mi le.
2 Ọkkàn mi, iwọ ti wi fu JEHOFA pe, Iwọ li Oluwa mi: ore mi kò de ọdọ rẹ,
3 Bikoṣe si ọdọ awọn enia mimọ ti o wà li aiye, ati si awọn ẹni rere, lara ẹniti didùn-inu mi gbogbo gbé wà.
4 Ibinujẹ awọn ti nyara ta ọlọrun omiran li ọrẹ yio pọ̀: ẹbọ ohun mimu èjẹ wọn li emi kì yio fi fu-ni, bẹ̀li emi kì yio da orukọ wọn li ẹnu mi.
5 JEHOFA ni ipín ti ilẹ-ini mi, ati ti ago mi: iwọ li o mu ìla mi duro.
6 Okùn tita bọ́ sọdọ mi ni ibi dara-dara; lõtọ, emi ni ipa ilẹ rere.
7 Emi o fi ibukún fu JEHOFA, ẹniti o ti nfu mi ni ìmọ; ọkkàn mi pẹlu nkọ́ mi ni wakati oru.
8 Emi ti gbé JEHOFA kà iwaju mi nigbagbogbo; nitori ti o wà li ọwọ́ ọtún mi, a kì yio ṣí mi nipò pada.
9 Nitori na ni inu mi ṣe dùn, ti ogo mi sì nyọ̀; ara mi pẹlu yio simi ni ireti.

Digitized by Google

10 Nitori ti iwọ kì yio fi ọkkàn mi silẹ ni ipò okú; bẹ̃ni iwọ kì yio jẹ ki Ẹni Mimọ́ rẹ ki o dibajẹ.

11 Iwọ o fi ipa ọ̀na lye hàn mi; ni iwaju rẹ li ẹkún ayọ̀ wà; li ọwọ́ ọtún rẹ ni didùn-inu wà lailai.

Psalmu 17.

GBỌ́ otitọ, Jehofa, fiye si igbe mi, fi etí si adura mi, ti kò ti ẹnu ẹ̀tan jade.

2 Jẹ ki idágba ọ̀rọ mi ki o ma ti iwaju rẹ jade wá; jẹ ki oju rẹ ki o ma wò ohun ti o ṣe dede.

3 Iwọ ti mọ̀ àiya mi; iwọ ti bẹ̀ mi wò li oru; iwọ ti dan mi wò, iwọ kì yio sì ri nkan; emi ti pin-nu rẹ̀ pe, ẹnu mi kì yio ṣẹ̀.

4 Nipa ti iṣẹ́ awọn enia, nipa ọ̀rọ ẹnu rẹ emi ti pa ara mi mọ́ kuro ni ipa alaparun.

5 Fi ìrin mi le ilẹ ni ipa rẹ, ki itẹ̀lẹ ẹsẹ mi ki o má ṣe yẹ̀.

6 Emi ti nkepè ọ, nitori pe iwọ o gbohùn mi, Ọlọrun: dẹ etí rẹ si mi, ki o sì gbọ́ ọ̀rọ mi.

7 Fi iṣeun-ifẹ́ iyanu rẹ hàn, iwọ ti ngbà awọn ti o gbẹ̀kẹ̀ wọn le ọ là, lọwọ́ awọn ti o dide si ọwọ́ ọtún rẹ.

8 Pa mi mọ́ bi ẹyin-oju, pa mi mọ́ labbẹ ojiji iyẹ́ apa rẹ,

9 Lọwọ́ awọn enia buburu ti nforo mi, lọwọ́ awọn ọtá ọkkàn mi ti o yi mi ká kiri.

10 Ọrá ara wọn sé wọn bò: ẹnu wọn ni nwọn fi nsọ̀rọ igberaga.

11 Nwọn ti yi wa ká nisisiyi ninu ìrin wa; nwọn ti gbé oju wọn le, ki nwọn ki o wọ́ wa silẹ;

12 Bi kiniu ti nṣe iwọra si ohun ọdẹ rẹ̀, ati bi ẹnipe ọmmọ kiniu ti o mba ni ibi ìkọkọ.

Digitized by Google

13 Dide, JEHOFA, ṣaju rẹ̀, rẹ̀ ẹ silẹ : gbà ọkkàn mi lọwọ́ awọn enia buburu, nipa idà rẹ :

14 Lọwọ́ awọn enia nipa ọwọ́ rẹ, JEHOFA, lọwọ́ awọn enia aiye, ti nwọn ni ipín ti wọn li aiye yi, ati ikùn ẹniti iwọ fi ohun iṣura rẹ ìkọkọ kún : awọn ọmmọ wọn yo, nwọn a sì fi iyokù ini wọn silẹ fu awọn ọmmọ wọn.

15 Bi o ṣe ti emi ni, emi o ma wò oju rẹ li ododo : yio tẹ́ mi lọrùn nigbati mo ba jí li aworan rẹ.

ALẸ IJỌ. 3.

PSALMU 18.

EMI o fẹ ọ, JEHOFA, agbara mi.

2 JEHOFA li apatta mi, ati odi lagbara mi, ati olugbala mi; Ọlọrun mi, agbara mi, ẹniti emi o gbẹkẹle; asà mi, ati iwo igbala mi, ati ile-iṣọ giga mi.

3 Emi o kepè JEHOFA, ti o yẹ lati ma yìn : bẽli a o sì gbà mi lọwọ́ awọn ọtá mi.

4 Ibinujẹ ikú yi mi ká, ati ìṣan awọn enia buburu dẹruba mi.

5 Ibinujẹ ipò okú yi mi ká kiri : ikẹkun ikú ti ṣaju mi.

6 Ninu iṣẹ́ mi emi kepè JEHOFA, emi sì sọkun pè Ọlọrun mi : o gbohùn mi lati inu tempeli rẹ̀ wá, ẹkún mi sì wá si iwaju rẹ̀, ani si etí rẹ̀.

7 Nigbana ni ilẹ mì, o sì wa-rìri; ipilẹ ti òke pẹlu ṣidi, ọ sì mì, nitori ti o binu.

8 Êfin ti ihò imọ rẹ̀ jade, ati iná lati ẹnu rẹ̀ wá njonirun : ẹyín nràn nipasẹ rẹ̀.

9 O tẹri ọrun ba pẹlu, o sì sọkalẹ wá : òkunkun sì mbẹ li atẹlẹsẹ rẹ̀.

Digitized by Google

10 O sì gùn ori kerubu, o sì fò : nitõtọ, o fò ni iyẹ apa afẹfẹ.
11 O fi òkunkun ṣe ibi ìkọkọ rẹ̀; agọ́ rẹ̀ ti o yi i ká li omi dudu, ati awọ-sanma oju ọrun ti o ṣú dudu.
12 Nipa imọlẹ iwaju rẹ̀, awọ-sanma ṣíṣu dudu rẹ̀ kọja lọ yinyín ati ogun-ná.
13 JEHOFA sán ãrá pẹlu li ọrun, Ọgá-ogo sì fọ̀ ohùn rẹ̀; yinyín ati ogun-ná.
14 Lõtọ, o rán ọfà rẹ̀ jade, o sì tú wọn ká; o sì kọ manamana rẹ̀, o sì fi ṣẹ́ wọn tútu.
15 Nigbana li awowo omi odò hàn, a sì ri ipilẹ aiye nipa ibawi rẹ, JEHOFA, nipa fifọn ẹmmí ihò imọ rẹ.
16 O ranṣẹ̀ lati oke wá, o mu mi, o fà mi jade wá lati inu omi nla.
17 O gbà mi lọwọ́ ọtá mi alagbara, ati lọwọ́ awọn ti o korira mi; nitori ti nwọn li agbara jù mi lọ.
18 Nwọn ṣaju mi li ọjọ ipọnju mi : ṣugbọn JEHOFA li alafẹhinti mi.
19 O mu mi jade pẹlu sinu ibi nla; o gbà mi, nitori ti inu rẹ̀ dùn si mi.
20 JEHOFA san a fu mi gẹgẹ bi ododo mi; gẹgẹ bi mimọ́ ọwọ́ mi li o san a fu mi.
21 Nitori ti mo ti nkiye si ọ̀na JEHOFA, emi kò fi ìka yà kuro lọdọ Ọlọrun mi.
22 Nitori pe gbogbo idajọ́ rẹ̀ li o wà niwaju mi, bẽli emi kò sì yẹ̀ ofin rẹ̀ kuro lọdọ mi.
23 Emi sì duro ṣinṣin niwaju rẹ̀, emi sì paramọ kuro lara ẹ̀ṣẹ̀ mi.
24 Nitorina ni JEHOFA ṣe san a fu mi gẹgẹ bi ododo mi, gẹgẹ bi mimọ́ ọwọ́ mi li oju rẹ̀.
25. Fu alãnu ni iwọ o fi ara rẹ hàn li alãnu; fu ẹniti o duro ṣinṣin ni iwọ o sì fi ara rẹ hàn ni diduro ṣinṣin;
26 Fu ọlọkàn mimọ́ ni iwọ o fi ara rẹ hàn

Digitized by Google

ni mimọ́; ati fu onrorò ni iwọ o fi ara rẹ hàn li onrorò.

27 Nitori ti iwọ o gbà awọn olupọnju; ṣugbọn iwọ o sọ oju igberaga kalẹ.

28 Nitori iwọ ni yio tàn fitila mi : JEHOFA Ọlọrun mi yio tàn imọlẹ si òkunkun mi.

29 Nitori pe nipa ti rẹ emi súre là inu ogun lọ ; ati nipa ti Ọlọrun mi emi fò ori odi kan.

30 Bi o ṣe ti Ọlọrun ni, ọna rẹ̀ pé : a ti ridi òrọ JEHOFA : on li asà fu gbogbo awọn ti o gbẹ̀kẹ̀le e.

31 Nitori pe tani ṣe Ọlọrun, bikoṣe JEHOFA? tabi tani ṣe apatta bikoṣe Ọlọrun wa ?

32 Ọlọrun li o fi agbara gbà mi li ọjá, o sì mu ọna mi pé.

33 O ṣe ẹsẹ mi dabi ẹsẹ agbọnrin, o sì gbé mi kà ibi giga mi.

34 O kọ́ ọwọ́ mi li ogun jijà, bẹ̃li ọrun irin ti apa mi ṣẹ́.

35 Iwọ ti fi asà igbala rẹ fu mi pẹlu : ọwọ́ ọtún rẹ sì gbé mi duro, ati iwa-pẹlẹ rẹ sọ mi di nla.

36 Iwọ sọ ìrin ẹsẹ mi di nla nisalẹ mi, ki kóko-ẹsẹ mi ki o má ṣe yẹ̀.

37 Emi ti lé awọn ọtá mi, emi sì ba wọn; bẹ̃li emi kò pada sẹhin titi a fi run wọn.

38 Emi ṣá wọn li ọgbẹ ti nwọn kò fi le dide : nwọn ṣubu li abbẹ ẹsẹ mi.

39 Nitori ti iwọ fi agbara dì mi li amure si ogun na : iwọ ti mu awọn ti o dide si mi tẹriba li ẹsẹ mi.

40 Iwọ sì fi ọrùn awọn ọtá mi fu mi pẹlu; ki emi ki o le run awọn ti o korira mi.

41 Nwọn kigbe, ṣugbọn kò si ẹniti o gbà wọn : ani si JEHOFA, ṣugbọn kò da wọn li ohùn.

Digitized by Google

42 Nigbana ni mo gún kun-na bi ekuru niwaju afẹfẹ : mo kó wọn jade bi egunrin ni ita.
43 Iwọ ti yọ mi kuro ninu ìja ti awọn enia; iwọ fi mi jẹ olori ti awọn keferi : enia ti emi kò ti mọ yio ma sìn mi.
44 Bi nwọn ba ti gburó mi, nwọn o gbà mi gbọ́ : awọn ọmmọ àjeji yio tẹ ori wọn ba fu mi.
45 Àiya yio pa awọn alejò, èru yio sì ma bà wọn ni ibi kọlọfin wọn.
46 JEHOFA mbẹ; olubukún si li apatta mi; ki a sì gbé Ọlọrun igbala mi leke.
47 Ọlọrun li o ngbẹsan mi, ti o sì ṣẹ́ awọn enia fu mi.
48 O gbà mi lọwọ́ awọn ọtá mi : pẹlu-pẹlu, iwọ gbé mi leke jù awọn ti o dide si mi lọ : iwọ ti gbà mi lọwọ́ ọkọnri alagbara ni.
49 Nitori na li emi o ṣe fi ìyin fu ọ, JEHOFA, li awujọ awọn keferi, emi o sì ma kọnrin ìyin si orukọ rẹ.
50 Igbala nla li o fi fu Ọbba rẹ; o sì fi ãnu hàn fu ẹni atorórosi rẹ, fu Dafidi, ati fu irú-ọmmọ rẹ lailai.

OWURỌ IJỌ. 4.

PSALMU 19.

AWỌN ọrun nsọ̀rọ ogo Ọlọrun; ati ofurufu nfi iṣẹ́ ọwọ́ rẹ hàn.
2 Ati ọjọ de ọjọ nfọhùn, ati oru de oru nfi ìmọ hàn.
3 Kò si ohùn kan tabi ède kan, nibiti a kò gbohùn wọn.
4 Ipa wọn là já gbogbo aiye, ati ọ̀rọ wọn de opin aiye : ninu wọn li o gbé pagọ fu õrùn;

Digitized by Google

5 Ti o dabi ọkọ iyawo ti njade ti iyẹwu rẹ wá, ti o sì nyọ̀ bi ọkọnri alagbara lati súre asa dije.

6 Ijade lọ rẹ ni lati opin ọrun wá, ati ayika rẹ sì de ipinlẹ rẹ : kò sì si ohun kan ti o fi ara pamọ́ kuro ninu oru rẹ.

7 Ofin JEHOFA pé, o nyi ọkkàn pada : ẹrí JEHOFA daniloju, o nsọ òpe di ọlọ́gbọn.

8 Aṣẹ JEHOFA tọ́, o nmu ọkkàn yọ̀ : ofin JEHOFA ni mimọ́, o nṣe imọlẹ oju.

9 Ẹ̀ru JEHOFA mọ́, pipẹ ni titi lai ; idajọ́ JEHOFA li otitọ ati ododo patapata.

10 Nwọn jù wura ni fifẹ, lõtọ, jù wura daradara lọ : nwọn sì dùn jù oyin lọ ati riro afara oyin.

11 Pẹlu-pẹlu nipa wọn li a ti ṣí iranṣẹ rẹ letí : ati ni pipamọ́ wọn ère pipọ̀ mbẹ.

12 Tali o le mọ̀ ìṣina rẹ̀ ? wẹ̀ mi mọ́ kuro ninu iṣiṣe ìkọkọ mi.

13 Fà iranṣẹ rẹ sẹhin pẹlu kuro ninu ẹ̀ṣẹ ikugbu ; má ṣe jẹ ki nwọn ki o jọba mi : nigbana li emi o duro ṣinṣin, emi o sì ṣe alaìṣẹ kuro ninu ẹ̀ṣẹ nla ni.

14 Jẹ ki ọ̀rọ ẹnu mi, ati iṣaro ọkkàn mi, ki o ṣe itẹwọgbà li oju rẹ, JEHOFA, agbara mi, ati oludande mi.

PSALMU 20.

KI JEHOFA ki o gbohùn rẹ li ọjọ́ ipọnju ; orukọ ti Ọlọrun Jakobu ki o dãbobo ọ.

2 Ki o rán iranlọwọ́ si ọ lati ibi mimọ́ wá, ki o sì tì ọ lẹhin lati Sion wá.

3 Ki o ranti ẹbọ ọrẹ rẹ gbogbo, ki o sì gbà ẹbọ sisọn rẹ.

4 Ki o fifu ọ gẹgẹ bi ti inu ọkkàn rẹ, ki o sì mu gbogbo ìmọ rẹ ṣẹ.

Digitized by Google

5 Awa o sì ma yọ̀ ni igbala rẹ, ati li orukọ Ọlọrun wa li awa o fi ọpágun wa de ilẹ: ki Jehofa ki o mu gbogbo adura rẹ ṣẹ.

6 Nigbayi ni mo to mọ̀ pe Jehofa gbà ẹni atorórosi rẹ̀ là; yio gbọ́ ọ lati ọrun mimọ́ rẹ̀ wá nipa agbara ti igbala ọwọ́ ọtún rẹ̀.

7 Awọn ẹlomiran ngbẹkẹle kẹ̀kẹ́, awọn ẹlomiran li ẹṣin; ṣugbọn awa o ranti orukọ Jehofa Ọlọrun wa.

8 A fà wọn lulẹ nwọn sì ṣubu: ṣugbọn awa dide, awa sì duro ṣinṣin.

9 Gbà-ni, Jehofa: ki ọba ki o gbọ́ nigbati awa ba nkigbe pè e.

Psalmu 21.

OBBA yio ma yọ̀ li agbara rẹ, Jehofa; ati ni igbala rẹ yio ti yọ̀ pọ̀ to!

2 Iwọ ti fi ifẹ́ ọkàn rẹ̀ fu u, iwọ ko sì dù u li ère ẹnu rẹ̀.

3 Nitori ti iwọ ti fi ibukún ore ṣaju rẹ̀: iwọ fi ade kìki wura de e li ori.

4 O tọrọ ẹmmí lọwọ́ rẹ, iwọ sì fi fu u, ani ọjọ gigun lai ati lailai.

5 Ogo rẹ̀ pọ̀ ni igbala rẹ: iyìn ati ọlá nla ni iwọ fi si i lara.

6 Nitori iwọ ti ṣe e li ẹni ibukún-fu julọ titi aiye: iwọ sì fi oju rẹ mu u yọ̀ gidigidi.

7 Nitori ti ọba gbẹkẹle Jehofa, ati nipa ãnu ti Ọgá-ogo kì yio ṣipò pada.

8 Ọwọ́ rẹ yio wá gbogbo awọn ọtá rẹ ri: ọwọ́ ọtún rẹ ni yio wá awọn ti o korira rẹ ri.

9 Iwọ o ṣe wọn bi ileru oniná ni igba ibinu rẹ: Jehofa yio gbé wọn mì ni ibinu rẹ̀, iná na yio sì jó wọn pa.

10 Ọmmọ wọn ni iwọ o run kuro ni ilẹ, ati irú-ọmmọ wọn kuro ninu awọn ọmmọ enia.

Digitized by Google

11 Nitori ti nwọn nrò ibi si ọ : nwọn ngbìro ete ìwa-ibi, ti nwọn kì yio le ṣe.

12 Nitorina ni iwọ o ṣe mu wọn pẹhinda, nigbati iwọ ba fi ọfà rẹ kàn ọṣán si oju wọn.

13 Ki iwọ ki o ma leke, JEHOFA, li agbara rẹ : bẹ̃li awa o ma kọnrin ti a o sì ma yìn agbara rẹ.

ALẸ IJỌ. 4.

PSALMU 22.

OLỌRUN mi, Ọlọrun mi, ẽṣe ti iwọ fi kọ̀ mi silẹ? ti iwọ sì jina si igbala mi, ati si ohùn igbe mi?

2 Ọlọrun mi, emi nkigbe li ọsán, ṣugbọn iwọ kò dahùn; ati ni igba oru emi kò dakẹ.

3 Ṣugbọn mimọ́ ni iwọ, ẹniti o tẹdo iyìn Israeli.

4 Awọn babba wa gbẹkẹle ọ : nwọn gbẹkẹle, iwọ sì gbà wọn.

5 Nwọn kigbe pè ọ, a sì gbà wọn : nwọn gbẹkẹle ọ, nwọn kò sì damu.

6 Ṣugbọn kòkoro li emi, kì sì ṣe enia; ẹgan ti awọn enia, ati ẹlẹya ti awọn enia.

7 Gbogbo awọn ti o ri mi nfi mi rẹrin ẹlẹya: nwọn yọ̀ sùti ète wọn, nwọn nmì ori wọn, wipe,

8 O gbẹkẹle JEHOFA ki o le gbà a là : jẹ ki o gbà a là, bi inu rẹ̀ ba dùn si i.

9 Ṣugbọn iwọ li ẹniti o mu mi jade lati inu wá : iwọ li o ṣe ipamọ́ mi nigbati mo rọ̀ mu ọmu iya mi.

10 Iwọ li a ti fi mi le lọwọ́ lati inu iya mi wá : iwọ li Ọlọrun mi lati inu iya mi wá.

11 Má ṣe jina si mi; nitori ti iyọnu sumọ́ etile; nitori ti kò si oluranlọwọ́.

Digitized by Google

12 Akọ malu pipọ̀ li o yi mi ká : akọ malu ti Baṣan ti o lagbara rọ̀gba yí mi ká.
13 Nwọn yà ẹnu wọn si mi, bi kiniu ti ndọdẹ kiri, ti nke ramu-ramu.
14 A tú mi da-nù bi omi, gbogbo egungun mi sì yẹ̀ lori ike : àiya mi dabi ida; o yọ́ larin inu mi.
15 Agbara mi di gbigbẹ bi apãdi; ahọn mi sì di mọ́ mi li ẹrẹkẹ; iwọ mu mi wá sinu erupẹ̀ ikú.
16 Nitori ti awọn ajá yi mi ká : ijọ awọn enia buburu ti ká mi mọ́ : nwọn lu mi li ọwọ́, nwọn sì lu mi li ẹṣẹ.
17 Mo le kà iye gbogbo egungun mi : nwọn nwò mi ṣọ̀n.
18 Nwọn pín aṣọ mi fu ara wọn, nwọn sì ṣẹ keke si aṣọ ileke mi.
19 Ṣugbọn iwọ má ṣe jina si mi, JEHOFA : agbara mi, yara lati ràn mi lọwọ́.
20 Gbà ọkàn mi lọwọ́ idà na; ẹni mi kan na ọwọ́ agbara ajá ni.
21 Gbà mi kuro li ẹnu kiniu ni : nitori ti iwọ ti gbohùn mi lati ibi iwo ti awọn agbanrere.
22 Emi o sọ̀rọ orukọ rẹ fu awọn arakọnri mi : li awujọ ijọ li emi o.ma yìn ọ.
23 Ẹnyin ti o bẹ̀ru JEHOFA, ẹ yìn i; gbogbo ẹnyin irú-ọmmọ Jakobu, ẹ yìn i logo : ki ẹ sì ma bẹ̀ru rẹ̀, gbogbo ẹnyin irú-ọmmọ Israeli.
24 Nitori ti kò kẹgan bẹ̃ni kò korira ipọnju ti awọn olupọnju; bẹ̃ni kò pa oju rẹ̀ mọ́ kuro lara rẹ̀; ṣugbọn nigbati o kigbe pè e, o gbọ́.
25 Nipa ti rẹ ni iyìn mi yio wà ninu ajọ nla : emi o san ileri ifẹ́ mi niwaju awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀.
26 Ọlọkàn tutù yio jẹ yio sì tẹ́ ẹ lọrùn :

Digitized by Google

awọn ti nwá a kiri yio yìn JEHOFA : àiya nyin yio wà lailai:

27 Gbogbo opin aiye ni yio ranti, nwọn o sì yipada si JEHOFA : ati gbogbo ibatan ti orilẹ èdè ni yio wolẹ sìn niwaju rẹ.

28 Nitori ijọba ni ti JEHOFA; on sì ni Bãlẹ ninu awọn orilẹ èdè.

29 Gbogbo awọn ti o sanra li aiye yio ma jẹ nwọn o sì ma sìn : gbogbo awọn ti nsọkalẹ lọ sinu erupẹ yio tẹriba niwaju rẹ, kò sì si ẹniti o le pa ọkàn ara rẹ mọ́ lãye.

30 Irú kan yio ma sìn i; a o sì kà a ni iran kan fu JEHOFA.

31 Nwọn o wá, nwọn o sì ma sọ̀rọ ododo rẹ fu awọn enia kan ti a o bí, pe o ti ṣe eyi.

PSALMU 23.

JEHOFA li oluṣọ agutan mi; emi kì yio ṣe alaìni.

2 O mu mi dubulẹ ninu papa oko tutù; o mu mi lọ si ìha omi didakẹ-rọrọ.

3 O mu ọkàn mi pada; o mu mi lọ nipa ọ̀na ododo nitori ti orukọ rẹ.

4 Nitõtọ, bi mo tilẹ nrìn larin afonifoji ti ojiji ikú, emi kì yio bẹ̀ru ibi kan; nitori ti iwọ pẹlu mi; ọgọ rẹ ati ọpá rẹ nwọn ntù mi ni inu.

5 Iwọ tẹ́ tabeli onjẹ silẹ niwaju mi li oju awọn ọtá mi; iwọ dà oróro si mi li ori; ago mi sì kún akún wọ́ si ilẹ.

6 Nitõtọ, ire ati ãnu ni yio ma tọ̀ mi lẹhin li ọjọ aiye mi gbogbo; emi o sì ma gbé inu ile JEHOFA lailai.

Digitized by Google

OWURỌ IJỌ. 5.

Psalmu 24.

TI Jehofa ni ilẹ, ati ẹkún rẹ; aiye, ati awọn ti o tẹdo sinu rẹ.
2 Nitori ti o fi idí rẹ sọlẹ lori awọn okun, o sì gbé e kalẹ lori awọn ìṣan-omi.
3 Tani yio gùn ori òke Jehofa lọ? tabi tani yio duro ni ibi mimọ́ rẹ?
4 Ẹniti o li ọwọ́ mimọ́, ati àiya funfun: ẹniti kò gbé ọkàn rẹ soke si asan, ti kò sì bura ẹ̀tan.
5 On ni yio ri ibukún gbà lọwọ́ Jehofa, ati ododo lọwọ́ Ọlọrun ti igbala rẹ.
6 Eyi ni iran awọn ti nṣe afẹri rẹ, ti nṣe afẹri oju rẹ Ọlọrun Jakobu.
7 Ẹ gbé ori nyin soke, ẹnyin ẹnu ọ̀na; ki ẹ sì gbé nyin soke, ẹnyin ilẹkun aiye-raiye; Ọba ogo yio sì wọ̀ inu ile lọ.
8 Tali Ọba ogo yi? Jehofa ti o le ti o sì lagbara, Jehofa ti o lagbara li ogun.
9 Ẹ gbé ori nyin soke, ẹnyin ẹnu ọ̀na; ani ki ẹ gbé wọn soke, ẹnyin ilẹkun aiye-raiye: Ọba ogo yio sì wọ̀ inu ile lọ.
10 Tali Ọba ogo yi? Jehofa awọn ọmmọ ogun, on na li Ọba ogo.

Psalmu 25.

JEHOFA iwọ ni mo gbé ọkàn mi soke si.
2 Ọlọrun mi, emi gbẹkẹle ọ: má ṣe jẹ ki oju ki o tì mi, má ṣe jẹ ki awọn ọtá mi ki o yọ̀ mi.
3 Lõtọ, má ṣe jẹ ki oju ki o tì ẹnikẹni ti

Digitized by Google

o duro tì ọ : awọn ti nṣè li àinidi li oju o tì.

4 Fi ọ̀na rẹ hàn mi, JEHOFA; kọ́ mi ni ipa ti rẹ.

5 Sìn mi li ọ̀na otitọ rẹ, ki o sì kọ́ mi : nitori iwọ li Ọlọrun igbala mi; iwọ ni mo duro tì li ọjọ gbogbo.

6 JEHOFA, ranti ãnu ati iṣeun-ifẹ rẹ ti o ni irọnu; nitori ti nwọn ti wà ni igba atijọ.

7 Má ṣe ranti ẹ̀ṣẹ igba ewe mi, ati irekọja mi : gẹgẹ bi ãnu rẹ iwọ ranti mi, JEHOFA, nitori ore rẹ.

8 Rere ati diduro ni JEHOFA : nitorina ni yio ṣe ma kọ́ ẹlẹṣẹ li ọ̀na na.

9 Ọlọkkàn tutù ni yio tọ́ li ọ̀na ni idajọ́, ati ọlọkkàn tutù ni yio kọ́ li ọ̀na rẹ̀.

10 Gbogbo ipa JEHOFA li ãnu ati otitọ fu irú awọn ti o pa majẹmu rẹ ati ẹrí rẹ mọ́.

11 Nitori orukọ rẹ, JEHOFA, dari ẹ̀ṣẹ mi jì, nitori ti o tobi.

12 Ọkọnri ewo li o bẹ̀ru JEHOFA? on ni yio kọ́ li ọ̀na ti yio yàn.

13 Ọkkàn rẹ̀ yio joko ninu ire, irú-ọmmọ rẹ̀ yio sì jogún aiye.

14 Aṣiri JEHOFA wà pẹlu awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀; yio sì fi wọn mọ majẹmu rẹ̀.

15 Oju mi mbẹ sipa ti JEHOFA, lai; nitori ti yio fà ẹsẹ mi yọ kuro ninu àwọn na.

16 Yipada si mi, ki o sì ṣãnu fu mi; nitori ti mo di ofo, mo sì di olupọnju.

17 Iṣẹ́ àiya mi di pupọ̀ : iwọ mu mi jade ninu ipọnju mi.

18 Wò ipọnju mi ati irora mi; ki o sì dari gbogbo ẹ̀ṣẹ mi jì mi.

19 Wò awọn ọtá mi, nwọn sá pọ̀; nwọn sì korira mi ni irira ìka.

20 Pa ọkkàn mi mọ́, ki o sì gbà mi:

Digitized by Google

má ṣe jẹ ki oju ki o tì mi; nitori ti mo gbẹkẹ mi le ọ.

21 Jẹ ki ìwa-titọ ati iduro ṣinṣin ki o pa mi mọ; nitori ti mo duro tì ọ.

22 Rà Israeli pada, Ọlọrun, kuro ninu iṣẹ rẹ gbogbo.

Psalmu 26.

SE idajọ mi, Jehofa; nitori ti mo ti nrìn ninu ìwa-titọ mi: emi ti ngbẹkẹle Jehofa pẹlu; njẹ ẹsẹ mi kì yio yẹ.

2 Wadi mi, Jehofa, ki o sì ridi mi; dan ọkkàn mi ati àiya mi wò.

3 Nitori ti iṣeun-ifẹ rẹ mbẹ li oju mi: emi sì ti nrìn ninu otitọ rẹ.

4 Emi kò ba awọn ẹni asan joko, bẹ̀li emi kì yio wọle tọ̀ awọn alayidayida.

5 Emi ti korira ijọ awọn onisẹ buburu; emi kì yio sì ba awọn enia buburu joko.

6 Emi o wẹ̀ ọwọ́ mi li alẹṣẹ: bẹ̀li emi o sì yi pẹpẹ rẹ ká, Jehofa:

7 Ki emi ki o le fi ohùn ọpẹ́ rò kalẹ, ti emi o sì ma sọrọ gbogbo iṣẹ́ iyanu rẹ.

8 Jehofa, emi ti nfẹ ibujoko ile rẹ, ati ibi ti agọ́ ọlá rẹ.

9 Má ṣe kó ọkkàn mi pọ̀ pẹlu awọn ẹlẹṣẹ, tabi ẹmmí mi pẹlu awọn enia ẹ̀jẹ.

10 Li ọwọ́ ẹniti ìwa ìka mbẹ, ọwọ́ ọtún wọn sì kún fu abẹtẹlẹ.

11 Ṣugbọn bi o ṣe ti emi, emi o ma rìn ninu ìwa-titọ mi: rà mi pada, ki o sì ṣãnu fu mi.

12 Ẹsẹ mi duro ni ibi titẹju: ninu awọn ijọ li emi o ma fi ibukún fu Jehofa.

Digitized by Google

ALẸ IJỌ. 5.

Psalmu 27.

JEHOFA ni imọlẹ mi ati igbala mi; tali emi o bẹ̀ru? Jehofa li agbara ẹmmí mi; onọ tali emi o kọ?

2 Nigbati awọn enia buburu, ani awọn ọtá mi, ati awọn abinọku mi, sumọ́ mi lati jẹ ẹran ara mi, nwọn kọsẹ nwọn ṣubu.

3 Bi ogun tilẹ dó tì mi, àiya mi kì yio fò: bi ogun tilẹ ṣí mi, ninu eyi li ọkkàn mi yio le.

4 Ohun kan li emi ntọrọ li ọdọ Jehofa, on na li emi o ma wá kiri; ki emi ki o le ma gbé inu ile Jehofa li ọjọ aiye mi gbogbo, ki emi ki o le ma wò ẹwà Jehofa, ki emi ki o sì ma bère ninu tempeli rẹ̀.

5 Nitori pe ni igba ipọnju on yio pa mi mọ́ ninu agọ́ rẹ̀: ni ibi ìkọkọ agọ́ rẹ̀ ni yio pa mi mọ́; yio sì gbé mi kà ori apatta kan.

6 Nigbayi li ori mi yio gbé soke ga jù awọn ọtá mi lọ yiká mi: nitorina li emi o ṣe irubọ ayọ̀ ninu agọ́ rẹ̀; emi o kọnrin, nitõtọ emi o kọnrin iyìn si Jehofa.

7 Gbohùn mi, Jehofa, nigbati mo ba fi ohùn mi pè: ṣãnu fu mi pẹlu, ki o sì da mi lohùn.

8 Nigbati iwọ wipe, Ẹ ma wá oju mi, àiya mi wi fu ọ pe, Jehofa, oju rẹ̀ li emi yio ma wá.

9 Má ṣe pa oju rẹ mọ́ rére kuro fu mi; má ṣe fi ibinu ṣa iranṣẹ rẹ tì: iwọ li o ti nṣe iranlọwọ mi; má fi mi silẹ, bẹ̃ni ki o má ṣe kọ̀ mi, Olọrun igbala mi.

10 Nigbati babba ati iya mi kọ̀ mi silẹ, nigbana ni Jehofa yio tẹwọgbà mi.

Digitized by Google

11 Kọ́ mi li ọ̀na rẹ, Jehofa, ki o sì tọ́ mi li ọ̀na gbangba, nitori awọn ọtá mi.
12 Má ṣe fi mi le ifẹ́ awọn ọtá mi lọwọ́ : nitori ti awọn ẹlẹ̃ri eke dide si mi, ati irú awọn ti nmi ẹmmí ìka.
13 O rẹ̀ mi tan, bikoṣe bi mo ti gbagbọ́ lati ri ire Jehofa, ni ilẹ alãye.
14 Duro tì Jehofa : ki o sì túju ka, yio sì mu ọ li àiya le : mo ni, duro tì Jehofa.

Psalmu 28.

IWỌ, Jehofa, apatta mi li emi o kigbe pè ; má ṣe dakẹ si mi : bi iwọ ba dakẹ si mi, ki emi ki o má ba dabi awọn ti o lọ sinu ihò.
2 Gbohùn ẹ̀bẹ mi, nigbati mo ba nkigbe pè ọ, nigbati mo ba gbé ọwọ́ mi soke siha ibi mimọ́ rẹ.
3 Má ṣe fà mi lọ pẹlu awọn enia buburu, ati pẹlu awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ, ti nsọ̀rọ alafia si ẹnikeji rẹ̀, ṣugbọn ìwa ìka mbẹ li ọkkàn wọn.
4 Fi fu wọn gẹgẹ bi iṣe wọn, ati gẹgẹ bi ìwa buburu ete wọn : fi fu wọn nipa iṣẹ́ ọwọ́ wọn ; fi ère wọn fu wọn.
5 Nitori ti nwọn kò kà iṣẹ́ Jehofa si, bẽni, tabi ṣiṣe ọwọ́ rẹ̀, on yio run wọn, kì yio sì gbé wọn ró.
6 Olubukun ni Jehofa, nitori ti o ti ngbohùn ẹ̀bẹ mi.
7 Jehofa li agbara ati asà mi ; on li àiya mi gbẹkẹle, a sì nràn mi lọwọ́ : nitorina inu mi dùn jọjọ ; emi o sì ma fi orin mi yìn i.
8 Jehofa li agbara wọn, on sì li agbara igbala ti ẹni atorórosi rẹ̀.
9 Gbà awọn enia rẹ là, ki o sì busi i fu ilẹ-ini rẹ : ma bọ́ wọn pẹlu, ki o sì ma gbé wọn leke lailai.

Digitized by Google

PSALMU 29.

EFIFU JEHOFA, ẹnyin ọmmọ alagbara, ẹ fi ogo ati agbara fu JEHOFA.

2 Ẹ fi ọllá fu JEHOFA, ti o yẹ fu orukọ rẹ̀; ẹ ma sìn JEHOFA ninu ẹwà mimọ́ rẹ̀.

3 Ohùn JEHOFA mbẹ lori omi pupọ̀: Ọlọrun ogo nsán ãrá: JEHOFA mbẹ lori omi nla pupọ̀.

4 Ohùn JEHOFA li agbara; ohùn JEHOFA kún fu ọllá nla.

5 Ohùn JEHOFA nfà igi opepe ya; lõtọ, JEHOFA nfà igi opepe Lebanon ya.

6 O mu wọn fò pẹlu bi ọmmọ malu; Lebanon on Sirion bi ọmmọ agbanrere.

7 Ohùn JEHOFA nyà bi ọwọ́ iná.

8 Ohùn JEHOFA nmì aginjù; JEHOFA nmì aginjù Kadeṣi.

9 Ohùn JEHOFA li o nmu abo agbọnrin bí, o sì fi igbó didi hàn: ati ninu tempeli rẹ̀ li olukuluku nsọ̀rọ ogo rẹ̀.

10 JEHOFA joko lori ìṣan-omi; nitõtọ, JEHOFA joko li Ọbba lailai.

11 JEHOFA yio fi agbara fu awọn enia rẹ̀; JEHOFA yio fi alafia busi i fu awọn enia rẹ̀.

OWURỌ IJỌ. 6.

PSALMU 30.

EMI o kokikí rẹ, JEHOFA; nitori iwọ li o gbé mi leke, ti iwọ kò sì jẹ ki awọn ọtá mi ki o yọ̀ mi.

2 JEHOFA Ọlọrun mi, emi nkigbe pè ọ, iwọ sì ti mu mi lara da.

3 JEHOFA, iwọ ti yọ ọkàn mi jade kuro

Digitized by Google

ninu isà okú : iwọ sì pa mi mọ́ lãye, ki emi ki o ma ba lọ sinu ihò.

4 Kọnrin si JEHOFA, ẹnyin enia rẹ̀ mimọ́, ki ẹ sì ma dupẹ ni iranti ti ìwa mimọ́ rẹ̀.

5 Nitori pe ni iṣẹ́jukan ni ibinu rẹ̀ pẹ́, li oju-rere rẹ̀ ni ìye gbé wà; bi ẹkún pẹ́ di alẹ́ kan, ṣugbọn ayọ̀ mbọ̀ li owurọ̀.

6 Ati ninu alafia mi emi ni, ipò mi kì yio pada lailai.

7 JEHOFA, nipa oju-rere rẹ̀, iwọ ti mu òke mi duro ṣinṣin : iwọ pa oju rẹ̀ mọ́, ẹnu yọ̀ mi.

8 Emi kigbe pè ọ, JEHOFA ; ati si JEHOFA li emi mbẹ̀bẹ̀ mi.

9 Ère kili o wà li ẹ̀jẹ̀ mi, nigbati mo ba lọ sinu ihò? Erupẹ̀ ni yio ma yìn ọ bi? on ni yio ma sọ otitọ rẹ̀ bi?

10 Gbọ́, JEHOFA, ki o sì ṣãnu fu mi : JEHOFA, iwọ ma ṣe oluranlọwọ́ mi.

11 Iwọ ti sọ ikãnu mi di ijó fu mi; iwọ ti bọ́ aṣọ ọ̀fọ̀ mi kuro, iwọ sì fi ayọ̀ di mi li amure idi.

12 Nitori idi eyi ki ogo mi ki o le ma kọnrin si ọ, ki o má sì ṣe dakẹ. JEHOFA Ọlọrun mi, emi o ma fi iyìn fu ọ lailai.

PSALMU 31.

JEHOFA, iwọ ni mo gbẹ̀kẹ̀ mi le; má ṣe jẹ́ ki oju ki o tì mi lai : gbà mi ninu ododo rẹ̀.

2 Dẹ etí rẹ̀ silẹ́ si mi; gbà mi nisisiyi : iwọ ma ṣe apatta agbara mi, fu ile àbo lati gbà mi là.

3 Nitori iwọ li apatta mi ati odi mi; nitorina nitori orukọ rẹ̀ ma ṣe itọ́ mi, ki o sì ma ṣe amọ̀na mi.

Digitized by Google

4 Yọ mi jade ninu àwọn ti nwọn nà silẹ fu mi nikọ̀kọ : nitori iwọ li agbara mi.

5 Li ọwọ́ rẹ ni mo fi ẹmmí mi le : iwọ li o ti rà mi silẹ, JEHOFA Ọlọrun otitọ.

6 Emi ti korira awọn ẹniti nfi etí si eke asan : ṣugbọn emi gbẹkẹle JEHOFA.

7 Emi o yọ̀, inu mi yio sì dùn ninu ãnu rẹ : nitori ti iwọ ti rò ti iṣẹ́ mi ; iwọ ti mọ̀ ọkkàn mi ninu ipọnju ;

8 Iwọ kò sì sé mi mọ́ si ọwọ́ ọtá ni : iwọ fi ẹsẹ mi tẹlẹ nibi àye nla.

9 Ṣãnu fu mi, JEHOFA, nitori ti emi wà ninu iṣẹ́ : oju mi fi ibinujẹ run, ọkkàn mi ati inu mi.

10 Emi fi ibinujẹ lò ọjọ mi, ati ọdún mi ti on ti imí-ẹ̀dun : agbara mi kù nitori ẹ̀ṣẹ mi, awọn egungun mi sì run.

11 Emi di ẹni ẹ̀gan ninu awọn ọtá mi gbogbo, ṣugbọn pẹlu-pẹlu ninu awọn aladugbo mi, mo sì di ìbẹru fu awọn ojulumọ̀ mi : awọn ti o ri mi lode nyẹra kuro fu mi.

12 Emi di ẹni igbagbé kuro ni iye bi okú : emi dabi ohun èlo fifọ́.

13 Nitori ti emi ti ngbọ́ ẹ̀gan ọpọ enia : ẹ̀ru wà niha gbogbo : nigbati nwọn ngbìmọ pọ̀ si mi, nwọn gbìro ati gbà ẹmmí mi kuro.

14 Ṣugbọn emi gbẹkẹle ọ, JEHOFA : emi ni, Iwọ li Ọlọrun mi.

15 Igba mi mbẹ li ọwọ́ rẹ : gbà mi li ọwọ́ awọn ọtá mi, ati li ọwọ́ awọn ti nṣe inunibini si mi.

16 Ṣe oju rẹ ki o mọlẹ si iranṣẹ rẹ lara : gbà mi nitori ti ãnu rẹ.

17 Má ṣe jẹ ki oju ki o tì mi, JEHOFA ; nitori ti emi ti nkepè ọ : enia buburu ni ki oju ki o tì, awọn ni ki o sì ke kuro fu isà okú.

18 Awọn ète eke ni ki a mu dakẹ ; ti nsọ̀rọ

Digitized by Google

ohun buburu ni igberaga ati li ẹgan si awọn olododo.

19 Ore rẹ ti tobi to, ti iwọ fi ṣura dè awọn ti o bẹru rẹ; ore ti iwọ ti ṣe fu awọn ti o gbẹkẹle ọ niwaju awọn ọmmọ enia!

20 Iwọ o pa wọn mọ ni ibi ìkọkọ iwaju rẹ kuro ninu irera enia: iwọ o pa wọn mọ ni ìkọkọ ninu agọ kan kuro ninu ìja ahọn.

21 Olubukun ni JEHOFA: nitori ti o ti fi iṣeun-ifẹ iyanu rẹ hàn mi ni ilu-nla olodi.

22 Nitori ti mo ti wi ni ikanju mi pe, A ke mi kuro niwaju rẹ: ṣugbọn iwọ ngbohùn ẹbẹ mi nigbati mo nkepè ọ.

23 Ẹ fẹ JEHOFA, gbogbo ẹnyin enia rẹ mimọ: JEHOFA npa onigbagbọ mọ, o sì san a li ọpọlọpọ fu awọn onise igberaga.

24 Ẹ túju ka, yio sì mu nyin li àiya le, gbogbo ẹnyin ti o ni ireti JEHOFA.

ALẸ IJỌ. 6.

PSALMU 32.

IBUKÚN ni fu ẹniti a dari irekọja rẹ jì, ẹniti a bò ẹṣẹ rẹ mọlẹ.

2 Ibukún ni fu ọkọnri na ẹniti JEHOFA kò kà ẹṣẹ si lọrun, ati ninu ẹmmí ẹniti ẹtan kò si.

3 Nigbati mo dakẹ, egungun mi di gbigbó nitori igbe mi li ọjọ gbogbo.

4 Nitori li ọsán ati li oru, ọwọ rẹ wuwo si mi lara: omi ara mi sì di ọdá ẽrun.

5 Emi jẹwọ ẹṣẹ mi fu ọ, ati ẹṣẹ mi li emi kò sì fi pamọ. Emi wipe, emi o jẹwọ irekọja mi fu JEHOFA: iwọ sì dari ẹbi ẹṣẹ mi jì.

6 Nitori eyi li olukuluku ẹni ìwa-bi-Ọlọrun

Digitized by Google

yio ma gbadura si ọ ni igba atiri rẹ : nitõtọ ninu ìṣan-omi nla, nwọn kì yio sumọ́ ọdọ rẹ̀.

7 Iwọ ni ibi ipamọ́ mi; iwọ o pa mi mọ́ kuro ninu iṣẹ́; iwọ o fi orin igbala yi mi ká kiri.

8 Emi o fi ẹsẹ rẹ le ọ̀na, emi o sì kọ́ ọ li ọ̀na ti iwọ o rìn : emi o ma fi oju mi tọ́ ọ.

9 Ki ẹnyin ki o má ṣe dabi ẹṣin, tabi bi ibaka, ti kò ni iyé ninu : ẹnu ẹniti a kò le ṣe alfi ijanu bọ̀, ki nwọn ki o ma ba sumọ́ ọ.

10 Ọpọ ikãnu ni yio wà fu enia buburu : ṣugbọn ẹniti o ba gbẹkẹle JEHOFA, ãnu ni yio yi i ká kiri.

11 Ki inu nyin ki o dùn niti JEHOFA, ẹ sì ma yọ̀, ẹnyin olododọ; ẹ sì ma kọnrin fu ayọ̀, gbogbo ẹnyin ti àiya nyin duro ṣinṣin.

PSALMU 33.

EMA yọ̀ niti JEHOFA, ẹnyin olododo : nitori ti iyìn yẹ fu ẹni diduro ṣinṣin.

2 Ẹ ma fi dùru yìn JEHOFA : ẹ ma fi èlo orin mimọ́ ati ohun ọ̀nà olokùn mẹwa kọnrin si i.

3 Ẹ kọn orin titun si i; ẹ ma fi ọgbọngbọn lù ohun ọ̀nà orin pẹlu ariwo.

4 Nitori ti ọ̀rọ JEHOFA tọ́; ati gbogbo iṣẹ́ rẹ̀ li a nṣe nitõtọ.

5 O fẹ otitọ ati idajọ́ : ilẹ aiye kún fu ãnu JEHOFA.

6 Nipa ọ̀rọ ti JEHOFA li aiye ti da; ati gbogbo ẹda wọn nipa ẹmmí ẹnu rẹ̀.

7 O gbá awọn omi okun jọ bi ẹnipe ekiti kan : o tò ibú jọ ni ile iṣura.

8 Ki gbogbo aiye ki o bẹ̀ru JEHOFA : ki gbogbo araiye ki o ma wà ninu ẹ̀ru rẹ̀.

Digitized by Google

9 Nitori ti o sòrọ, o sì ti ṣẹ; o paṣẹ, o sì duro ṣinṣin.
10 JEHOFA mu ìmọ awọn keferi di asan: o mu arekereke awọn enia ṣaki.
11 Ìmọ JEHOFA duro lailai, ìro inu rẹ lati iran-diran.
12 Ibukún ni fu orilẹ ède na, Ọlọrun ẹniti JEHOFA ṣe; ati awọn enia na ti o ti yàn ṣe ini rẹ.
13 JEHOFA wò lati ọrun wá, o ri gbogbo awọn ọmmọ enia.
14 Lati ibujoko rẹ o wò gbogbo awọn araiye.
15 O ṣe àiya wọn bakan na; o wò gbogbo awọn iṣẹ wọn.
16 Ko si ọbba kan ti ati ọwọ́ òpọ ogun gbàla: a kò ti ipa agbara pupọ gbà alagbara là.
17 Ohun asan li ẹṣin fu igbala: bẽni kì yio fi agbara nla rẹ gbà ẹnikẹni là.
18 Kiye si i, oju JEHOFA mbẹ lara awọn ti o bẹ̀ru rẹ, lara awọn ti nreti nipa ãnu rẹ;
19 Lati gbà ọkkàn wọn là lọwọ́ ikú, ati lati pa wọn mọ́ lãye nigba ìyan.
20 Ọkkàn wa duro dè JEHOFA: on ni iranlọwọ wa ati asà wa.
21 Nitori ti ọkkàn wa yio yọ̀ niti rẹ, nitori ti awa ti gbẹkẹle orukọ rẹ mimọ́.
22 Ki ãnu rẹ, JEHOFA, ki o wà lara wa, gẹgẹ bi awa ti nṣe ireti rẹ.

PSALMU 34.

EMI o ma fi ibukún fu JEHOFA nigbagbogbo: iyìn rẹ yio ma wà li ẹnu mi titi lai.

Digitized by Google

2 Ọkkàn mi yio ma ṣogo rẹ̀ niti JEHOFA : awọn onirẹlẹ yio gbọ́, inu wọn yio sì ma dùn.
3 Gbé JEHOFA ga pẹlu mi, ki a sì jumọ gbé orukọ rẹ̀ leke.
4 Emi ṣe afẹri JEHOFA, o sì gbohùn mi, o sì gbà mi kuro ninu gbogbo ìbẹru mi.
5 Nwọn wò tọ̀ ọ, imọlẹ sì mọ wọn : oju wọn kò sì tì.
6 Ọkọnri olupọnju yi kigbe pè, JEHOFA sì gbohùn rẹ̀, o sì gbà a là ninu gbogbo ipọnju rẹ̀.
7 Angeli JEHOFA yi awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀ ká, o sì gbà wọn.
8 Tọ́ ọ wo, ki o sì ri pe rere ni JEHOFA : alabukun-fu li ọkọnri na ti o gbẹkẹle e.
9 Ẹ bẹ̀ru JEHOFA, ẹnyin enia rẹ̀ mimọ́ : nitori ti kò si aìni fu awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀.
10 Awọn ọmmọ kiniu a ma ṣe alaìni, ebi a sì ma pa wọn : ṣugbọn awọn ti nwá JEHOFA kì yio ṣe alaìni ohun ti o dara.
11 Wá, ẹnyin ọmmọ, fi etí si mi : emi o kọ́ nyin li ẹ̀ru JEHOFA.
12 Ọkọnri ewo li o nfẹ̀ ìye, ti o sì nfẹ̀ ọjọ pipẹ, ki o le ma ri rere?
13 Pa ahọn rẹ mọ́ kuro ninu ibi, ati ète rẹ̀ kuro li ẹ̀tan sisọ.
14 Lọ kuro ninu ibi, ki o sì ma ṣe rere ; ma wá alafia, ki o sì lepa rẹ̀.
15 Oju JEHOFA mbẹ lara awọn olododo, etí rẹ̀ sì ṣí si igbe wọn.
16 Oju JEHOFA kan si awọn ti nṣe buburu, lati ke iranti wọn kuro lori ilẹ.
17 Awọn olododo nke, JEHOFA sì gbọ́, o sì yọ wọn jade ninu iṣẹ́ wọn gbogbo.
18 JEHOFA mbẹ letì ọdọ awọn ti ṣe onirobinujẹ ọkkàn ; o sì gbà irú awọn ti ṣe onirora ọkkàn là.

Digitized by Google

19 Ọpọlọpọ ni ipọnju ti olododo : ṣugbọn Jehofa gbà a ninu wọn gbogbo.
20 O pa gbogbo egungun rẹ̀ mọ́ : kò si ọkan ti o ṣẹ́ ninu wọn.
21 Ibi ni yio pa enia buburu : ati awọn ti o korira olododo ni yio jẹbi.
22 Jehofa rà ọkkàn awọn iranṣẹ rẹ̀ : ọkan ninu awọn ti o gbẹ̀kẹ̀le e kì yio jẹbi.

OWURỌ IJỌ. 7.

Psalmu 35.

GBÀ ọran mi rò, Jehofa, ti emi ti awọn ti mba mi jà : fi ìja fu awọn ti mba mi jà.
2 Di asà on apatta mu, ki o sì dide fu iranlọwọ mi.
3 Fà ọkọ na yọ pẹlu, ki o sì dè ọna awọn ti nṣe inunibini si mi : wi fu ọkkàn mi pe, emi ni igbala rẹ.
4 Ki nwọn ki o damu ki a sì tì awọn ti nwá ọkkàn mi loju : ki a sì mu wọn pada, ki a sì damu awọn ti ngbìro ipalara mi.
5 Ki nwọn ki o dabi ìyangbo niwaju afẹfẹ : ki angeli Jehofa ki o ma lé wọn.
6 Ki ọna wọn ki o ṣú òkunknn ki o sì ma yọ́ : ki angeli Jehofa ki o sì ma ṣe inunibini si wọn.
7 Nitori pe, li ainidi ni nwọn dẹ àwọn wọn silẹ fu mi ni ihò, ti nwọn wà silẹ fu ọkkàn mi li alleṣẹ.
8 Ki iparun ki o wá si ori rẹ̀ li ojijì ; àwọn rẹ̀ ti o dẹ, ki o mu on tikara rẹ̀ : ninu iparun na ni ki o ṣubu si.
9 Ọkkàn mi yio sì ma yọ̀ niti Jehofa : yio sì ma yọ̀ ninu igbala rẹ̀.

Digitized by Google

10 Gbogbo egungun mi ni yio wipẹ, JEHOFA, tali o dabi iwọ, ti ngbà talakà lọwọ́ awọn ti o li agbara jù u lọ, ani talakà ati alàìni, lọwọ́ ẹniti mbà a jẹ?
11 Awọn ẹlẽri eke dide; nwọn kà ohun ti emi kò mọ̀ si mi lọrùn.
12 Nwọn fi buburu san ore fu mi lati gbà mi li ọkkàn lọ.
13 Ṣugbọn bi o ṣe ti emi ni, nigbati ara wọn kò dá, aṣọ àwẹ li aṣọ mi: mo fi àwẹ rẹ̀ ọkkàn mi silẹ; adura mi sì pada si mi li àiya.
14 Emi ṣe ara mi bi ẹnipe ọrẹ́ tabi arakọnri mi tilẹ ni; emi fi ibinujẹ tẹriba bi ẹniti nṣọfọ iya rẹ̀.
15 Ṣugbọn ninu ipọnju mi nwọn yọ̀, nwọn sì kó ara wọn jọ: awọn enia-kenia kó ara wọn jọ si mi, emi kò sì mọ̀; nwọn nfà mi ya, nwọn kò dakẹ:
16 Pẹlu awọn agabagebe ẹlẹya li apeje, nwọn npa ehin wọn si mi.
17 OLUWA, iwọ o ti ma wò pẹ to? yọ ọkkàn mi kuro ninu iparun wọn, ẹni mi kan na lọwọ́ awọn kiniu.
18 Emi o ṣe ọpẹ́ fu ọ ninu ajọ nla ni: emi o ma yìn ọ li awujọ ọpọ enia.
19 Má ṣe jẹ ki awọn ti nṣe ọtá mi lodi ki o yọ̀ mi; bẽni ki o má sì ṣe jẹ ki awọn ti o korira mi li ainidi ki o ma ṣẹju si mi.
20 Nitori ti nwọn kò sọ̀rọ alafia: ṣugbọn nwọn humọ̀ ọran ẹtan si awọn enia jẹjẹ ilẹ na.
21 Nitõto, nwọn ya ẹnu wọn silẹ si mi, nwọn wipe, Ã, ã, oju wa ti ri i.
22 Eyi ni iwọ ti ri, JEHOFA: má ṣe dakẹ: OLUWA, má ṣe jina si mi.
23 Rú ara rẹ soke, ki o sì jí si idajọ́ mi, ati si ọran mi, Ọlọrun mi ati OLUWA mi.

Digitized by Google

24 Ṣe idajọ́ mi, JEHOFA Ọlọrun mi, gẹgẹ bi ododo rẹ; ki o má sì ṣe jẹ ki nwọn ki o yọ̀ mi.
25 Má ṣe jẹ ki nwọn ki o wi ninu ọkàn wọn pe, Ã, bẽli awa nfẹ ẹ: má ṣe jẹ ki nwọn ki o wipe, Awa ti gbé mì i.
26 Ki oju ki o tì wọn ki nwọn ki o sì damu pọ̀, ti nyọ̀ si ifarapa mi : ki a fi itiju ati àbukun wọ̀ wọn li aṣọ ti ngberaga si mi.
27 Jẹ ki nwọn ki o ma hó fu ayọ̀, nwọn o sì ma ṣe inu didùn, ti nṣe oju-rere si ododo mi : lõtọ ki nwọn ki o ma wi titi pe, JEHOFA ni ki a ma gbéga soke, ti o ni inu didùn si alafia iranṣẹ rẹ̀.
28 Ahọn mi yio sì ma sọ̀rọ ododo rẹ, ati ti iyìn rẹ li ọjọ gbogbo.

PSALMU 36.

IREKỌJA ti enia buburu wi ninu ọkkàn mi pe, ẹ̀ru Ọlọrun kò si niwaju rẹ̀.
2 Nitori ti o npọ́n ara rẹ̀ li oju ara rẹ̀, titi a o fi ri ẹ̀ṣẹ rẹ̀ di irira.
3 Ọ̀rọ ẹnu rẹ̀ li ẹ̀ṣẹ on ẹ̀tan : o ti fi iṣe ọgbọ́n ati iṣe rere silẹ.
4 O ngbìro ìwa ìka lori ẹní rẹ̀ : o fi ara dè ọ̀na ti kò dara; on kò korira ibi.
5 JEHOFA, ãnu rẹ mbẹ li ọrun; otitọ rẹ dé awọ-sanma.
6 Ododo rẹ dabi òke Ọlọrun; ibú nla ni idajọ́ rẹ : JEHOFA, iwọ pa enia ati ẹranko mọ́.
7 Ọlọrun, iṣeun-ifẹ́ rẹ ti dara to! nitori na li awọn ọmmọ enia yio ma gbẹkẹ wọn le abbẹ ojiji iyẹ́ apa rẹ.
8 Oróro ile rẹ yio tẹ́ wọn lọrùn gidigidi; iwọ o sì mu wọn mọmi ninu odò ifẹ́ rẹ.

Digitized by Google

9 Nitori pe pẹlu rẹ li orisun ìye wà : ninu imọlẹ rẹ li awa o ma ri imọlẹ.
10 Mu iṣeun-ifẹ rẹ pẹ si awọn ti o mọ ọ; ati ododo rẹ fu awọn ti alàiya diduro.
11 Má ṣe jẹ ki ẹṣẹ agberaga ki o wá si mi, ki o má sì jẹ ki ọwọ́ enia buburu ki o ṣí mi ni ipò.
12 Nibẹ̀ li awọn oniṣẹ̀ èṣẹ gbé ṣubu : a rẹ̀ wọn silẹ, nwọn kì yio sì le dide.

ALẸ IJỌ. 7.

Psalmu 37.

MÁ ṢE ikanra nitori awọn oluṣe buburu, kì iwọ ki o máṣe ilara nitori awọn oniṣẹ̀ èṣẹ.
2 Nitori ti a o ke wọn lùlẹ nisisiyi bi ikoriko, nwọn o sì rọ bi eweko tutù.
3 Gbẹkẹle Jehofa, ki o sì ma ṣe rere; bẽni iwọ o ma gbé ilẹ na, nitõtọ li a o sì ma bọ́ ọ.
4 Ṣe ifẹ́ inu ara rẹ si Jehofa pẹlu, on o sì fi ifẹ́ inu rẹ̀ fu ọ.
5 Fi ọna rẹ le Jehofa lọwọ́; gbẹkẹle e pẹlu; yio sì mu u ṣẹ.
6 Yio sì mu ododo rẹ jade bi imọlẹ, ati idajọ́ rẹ bi ọsán gangan.
7 Iwọ simi niti Jehofa, ki o sì fi sũru duro dè e : má ṣe ikanra nitori ẹniti o nṣe rere li ọna rẹ̀, nitori ọkọnri na ti o nmu èro buburu ṣẹ.
8 Dakẹ inu bíbi, ki o sì kọ̀ ikan-nu silẹ : má ṣe ikanra bi o ti wù ki o ṣe lati ṣe buburu.
9 Nitori ti a o ke awọn oluṣe buburu kuro : ṣugbọn awọn ti o duro tì Jehofa ni yio jogún ilẹ aiye.

Digitized by Google

10 Nitori pe nigba diẹ, awọn enia buburu kì yio si : nitõtọ iwọ o fi ara balẹ wò ipò rẹ̀ kì yio sì si.

11 Ṣugbọn awọn ọlọkkàn tutù ni yio jogún ilẹ aiye; nwọn o sì ma ṣe inu didùn si ara wọn ninu ọ̀pọlọpọ alafia.

12 Enia buburu di rikisí si olõtọ, o sì pa ehin rẹ̀ keke si i lara.

13 Oluwa yio rẹrin rẹ̀; nitori ti o ri pe ọjọ rẹ̀ mbọ̀.

14 Awọn enia buburu ti fà idà yọ, nwọn sì ti fà ọrun wọn le, lati sọ awọn talakà ati alaìni kalẹ, ati lati pa irú awọn ti ṣe ọlọ̀rọ̀ diduro.

15 Idà wọn yio wọ̀ àiya ara wọn lọ, ọrun wọn yio sì ṣẹ́.

16 Ohun diẹ ti olododo ni, o sanjù ọrọ̀ ti ọ̀pọ awọn enia buburu.

17 Nitori ti a o ṣẹ́ apa awọn enia buburu : ṣugbọn Jehofa di olododo mu.

18 Jehofa mọ̀ ọjọ ẹni iduro ṣinṣin : ati ilẹ-ini wọn yio wà lailai.

19 Oju kì yio tì wọn ni igba ibi : ati li ọjọ ìyan a o tẹ́ wọn lọrùn.

20 Ṣugbọn awọn enia buburu yio ṣegbé, awọn ọtá Jehofa yio dabi ọrá ọdọ agutan : nwọn o run; ẽfin ni nwọn o run si.

21 Awọn enia buburu wín, nwọn kò si pada san : ṣugbọn olododo a ma ṣãnu, a sì ma fifu-ni.

22 Nitori irú awọn ẹni ibukún rẹ̀ ni yio jogún aiye; awọn ẹni egún rẹ̀ li a o ke kuro.

23 A ṣe ìlana ẹsẹ enia rere lati ọwọ́ Jehofa wá : o sì ṣe inu didùn nipa ọ̀na rẹ̀.

24 Bi o tilẹ ṣubu, a kì yio ta a nù kuro patapata : nitori ti Jehofa fi ọwọ́ rẹ̀ tì i.

Digitized by Google

25 Emi ti wà li ewe, emi sì dàgba; emi kò ti ri ki a kọ̀ olododo silẹ, tabi ki irú-ọmmọ rẹ̀ ki o ma ṣagbe onjẹ.
26 Alãnu li on nigba-gbogbo, a ma wín-ni; a sì ma busi i fu irú-ọmmọ rẹ̀.
27 Lọ kuro ninu ibi, ma sì ṣe rere; ki o sì ma joko lailai.
28 Nitori ti JEHOFA fẹ idajọ́, kò sì kọ̀ awọn enia mimọ́ rẹ̀ silẹ; a sì pa wọn mọ́ lailai: ṣugbọn irú-ọmmọ ti awọn enia buburu li a o ke kuro.
29 Olododo ni yio jogún ilẹ aiye, yio sì ma gbé inu rẹ̀ lailai.
30 Ẹnu olododo ni ima sọ̀rọ ọgbọ́n, ahọn rẹ̀ a sì ma sọ̀rọ idajọ́.
31 Ofin Ọlọrun rẹ̀ mbẹ li àiya rẹ̀; ọkan ninu ìrin rẹ̀ kì yio yẹ̀.
32 Ẹni buburu nṣọ olododo, o sì nwá ọ̀na lati pa a.
33 JEHOFA kì yio fi i le e lọwọ́, kì yio sì da a lẹbi nigbati a ba nṣe idajọ́ rẹ̀.
34 Duro tì JEHOFA, ki o sì ma pa ọ̀na rẹ̀ mọ́, yio sì gbé ọ leke lati jogún ilẹ aiye: nigbati a ba ke awọn enia buburu kuro, iwọ o ri i.
35 Emi ti nri enia buburu ninu agbara nla, o sì fi ara rẹ̀ gbilẹ bi igi tutù nla.
36 Ṣugbọn o kọja lọ, sì kiye si i, kò si mọ́: lõtọ, emi wá a kiri, ṣugbọn a kò le ri i.
37 Ma kiye si ẹni pipé, ki o sì ma wò ẹni diduro ṣinṣin: nitori alafia li opin ọkọnri na.
38 Ṣugbọn awọn alarekọja li a o parun pọ̀: opin awọn enia buburu li a o ke kuro.
39 Ṣugbọn lati ọwọ́ JEHOFA wá ni ìgbala ti awọn olododo: on li agbara wọn ni igba ipọnju.
40 JEHOFA yio sì ràn wọn lọwọ́, yio sì

Digitized by Google

gbà wọn : yio sì gbà wọn lọwọ́ awọn enia buburu, yio sì gbà wọn là, nitori ti nwọn gbẹ́kẹ́le e.

OWURỌ́ IJỌ. 8.

Psalmu 38.

JEHOFA má ṣe ba mi wi ninu ibinu rẹ : bẹ̃ni ki o má sì ṣe nà mi ni gbigbona ibinujẹ rẹ.

2 Nitori ti ọfà rẹ kàn mọ́ mi ṣinṣin, ọwọ́ rẹ sì kì mi wọ́ mọlẹ.

3 Kò si ibi yiyè li ara mi nitori ibinu rẹ ; bẹ̃ni kò si alafia li egungun mi nitori ẹ̀ṣẹ̀ mi.

4 Nitori ti ẹ̀ṣẹ̀ mi bori mi mọlẹ : bi ẹrù wuwo, o wuwo jù fu mi.

5 Ọgbẹ mi nrùn o sì dibajẹ nitori iwère mi.

6 Emi njowere ; ori mi tẹ̀ ba gidigidi ; emi ngbàwẹ rìn kiri li ọjọ gbogbo.

7 Nitori ti ìha mi kún fu arun ẹgbin : kò sì si ilera li ara mi.

8 Ara mi hù, o sì kan bajẹ : emi ti nke irora nitori alsimi àiya mi.

9 Cluwa gbogbo ifẹ́ mi mbẹ niwaju rẹ ; irora mi kò sì pamọ́ kuro lọdọ rẹ.

10 Àiya mi nmí-hẹlẹ, agbara mi yẹ̀ mi silẹ : bi o ṣe ti imọlẹ oju mi ni kò si lara mi.

11 Awọn olufẹ ati awọn ọrẹ́ mi duro li òkere kuro ni ìna mi, ati awọn ibatan mi duro li òkere rere.

12 Awọn pẹlu ti nwá ọkkàn mi dẹkun silẹ fu mi : ati awọn ti nwá ifarapa mi nsọ̀rọ ohun buburu, nwọn sì ngbìro ẹ̀tan li ọjọ gbogbo.

13 Ṣugbọn emi, bi aditi emi kò gbọ́ ; ati bi odi ti kò ya ẹnu rẹ̀.

Digitized by Google

14 Bẹ̀ni mo dabi ọkọnri ti kò gbọran, ati li ẹnu ẹniti ibawi kò si.
15 Nitori, JEHOFA, iwọ li emi duro dè, iwọ o gbọ́, OLUWA Ọlọrun mi.
16 Nitori ti mo wipe, Gbohùn mi, ki nwọn ki o ma ba yọ̀ mi : nigbati ẹsẹ mi ba yọ, nwọn o ma gbé ara wọn ga si mi.
17 Emi mọkun tan, ikãnu mi sì mbẹ nigbagbogbo niwaju mi.
18 Nitori ti emi o sọ ẹ̀ṣẹ mi; emi o kãnu fu ẹ̀ṣẹ mi.
19 Ṣugbọn ara yá awọn ọtá mi, ara wọn le : awọn ti o sì korira mi lalẹ̀ npọ̀ si i.
20 Awọn ti o sì nfi buburu san rere li awọn ọtá mi; nitori emi ntọ̀pa ohun ti ẹ̀ re.
21 JEHOFA, má ṣe kọ̀ mi silẹ : Ọlọrun mi, má ṣe jina si mi.
22 Yara lati ràn mi lọwọ́, OLUWA igbala mi.

PSALMU 39.

MO ni, emi o ma kiye si ọ̀na mi, ki emi ki o má fi ahọn mi ṣẹ̀ : emi o fi ijanu ko ara mi li ẹnu, nigbati enia buburu ba mbẹ niwaju mi.
2 Mo fi idakẹ yadi, mo tilẹ pa ẹnu mi mọ́ kuro li ọ̀rọ rere; ibinujẹ mi sì ru soke.
3 Àiya mi gbona ninu mi, nigbati emi sì nronu iná ràn : nigba na ni mo fi ahọn mi sọ̀rọ.
4 JEHOFA, jẹ ki emi ki o mọ̀ opin mi, ati ìwọn ọjọ́ mi, bi o ti ri; ki emi ki o le mọ̀ igba ti mo ni nihin.
5 Kiye si i, iwọ ti sọ ọjọ́ mi dabi ibú atẹlẹwọ; ọjọ́ ori mi sì dabi asan niwaju rẹ : nitõtọ olukuluku enia ninu ijoko rere rẹ̀ asan ni patapata.

Digitized by Google

6 Nitõtọ li aworan asan li enia gbogbo nrìn : nitõtọ ni nwọn nyọ ara wọn lẹnu li asan : o nkó ọrọ jọ, kò sì mọ ẹniti yio kó wọn lọ.
7 Njẹ nisisiyi, Oluwa, kini mo duro dè? ireti mi mbẹ li ọdọ rẹ.
8 Gbà mi ninu irekọja mi gbogbo : ki o má sì sọ mi di ẹgan ti awọn enia buburu.
9 Mo yadi, emi kò ya ẹnu mi; nitori pe iwọ li o ṣe e.
10 Mu ọwọ́ ìna rẹ kuro li ara mi : emi ṣegbé tan nipa lja ọwọ́ rẹ.
11 Nigbati iwọ ba fi ibawi kìlọ fu enia nitori ẹṣẹ, iwọ a ṣe ẹwà rẹ aparun bi kòkoro aṣọ : nitõtọ asan li enia gbogbo.
12 JEHOFA, gbọ́ adura mi, ki o sì fi etí si ẹkún mi; ki o má ṣe pa ẹnu rẹ mọ́ si omije mi : nitori alejò li emi lọdọ rẹ, ati atipo, bi gbogbo awọn babba mi ti ri.
13 Da mi si, ki emi li agbara, ki emi ki o to lọ kuro nihinyi, ati ki emi ki o to ṣe alaìsi.

PSALMU 40.

NI diduro emi duro dè JEHOFA; o sì dẹti si mi, o sì gbohùn ẹkún mi.
2 O sì mu mi gòke pẹlu lati inu ihò kan ariwo jade wá, lati inu erupẹ̀ ẹrẹ̀, o sì fi ẹsẹ mi kà ori apatta, o sì fi ẹsẹ ìrin mi lelẹ.
3 O sì ti fi orin titun si mi li ẹnu, ani orin iyìn si Ọlọrun wa : ọpọ enia ni yio ri i, ti yio sì bẹ̀ru, ti yio sì gbẹkẹle JEHOFA.
4 Olubukún-fu li ọkọnri na ti o fi JEHOFA ṣe igbẹkẹle rẹ̀, ti kò sì kà onirera si, tabi irú awọn ti nyà si ìha eke.
5 JEHOFA Ọlọrun mi, ọpọlọpọ ni iṣẹ́ iyanu ti iwọ ti nṣe, ati ìro inu rẹ sipa ti wa : a kò le

Digitized by Google

kà wọn fu ọ li ẹsẹ-ẹsẹ : bi emi o wi ti emi o sọrọ wọn, nwọn jù ohun kikà lọ.

6 Ẹbọ ati ọrẹ iwọ kò fẹ; etí mi ni iwọ ti ṣí : ọrẹ ẹbọ sisọn, ati ọrẹ ẹbọ èṣẹ on ni iwọ kò bère.

7 Nigbana ni mo wipe, Kiye si i, emi de : ninu àpo iwe ni li a gbé kọwe mi pe.

8 Inu mi dùn lati ṣe ifẹ rẹ, Ọlọrun mi : nitõto ofin rẹ mbẹ li àiya mi.

9 Emi ti wasu ododo ninu awujọ nla : kiye si i, emi kò pa ète mi mọ́, JEHOFA, iwọ mọ̀.

10 Emi kò pa ododo rẹ mọ́ li aiya mi, emi ti sọrọ otitọ ati igbala rẹ : emi kò sì pa iṣeun-ifẹ rẹ ati otitọ rẹ mọ́ kuro lọdọ ijọ nla ni.

11 Iwọ má ṣe fà ãnu rẹ ti o rọnu sẹhin kuro lọdọ mi, JEHOFA : ki iṣeun-ifẹ rẹ ati otitọ rẹ ki o ma pa mi mọ́ pẹ titi.

12 Nitori pe ọ̀pọlọpọ ibi li o yi mi ká kiri : èṣẹ mi dì mọ́ mi, bẽli emi kò le gbé oju wò oke; nwọn jù irun ori mi lọ : nitori na àiya mi pa mi.

13 Ki o wù ọ, JEHOFA, lati gbà mi : JEHOFA, yara lati ràn mi lọwọ́.

14 Ki oju ki o tì wọn, ki nwọn ki o sì damu pọ̀, ti nwá ọkkàn mi lati parun; ki a sì lé wọn pada sẹhin, ki a sì dojutì awọn ti nfẹ mi ni ibi.

15 Ki nwọn ki o di ofo fu ère ìtiju awọn ti nwi fu mi pe, Ã, ã.

16 Ki gbogbo awọn ti nwá ọ ki o ma yọ̀, ki inu wọn ki o sì ma dùn sipa ti rẹ : ki irú awọn ti o sì fẹ igbala rẹ ki o ma wi nigba-gbogbo pe, Gbígbe-ga ni JEHOFA.

17 Ṣugbọn talakà ati alalìni li emi; Oluwa sì nṣe iranti mi : iwọ ni iranlọwọ mi ati olugbala mi; má ṣe pẹ titi, Ọlọrun mi.

Digitized by Google

ALẸ IJỌ. 8.

Psalmu 41.

IBUKÚN ni fu ẹniti nrò ti alàllera, Jehofa yio gbà a là ni igba ipọnju.

2 Jehofa yio pa a mọ́, yio sì mu u wà lãye; a o sì bukún ọ fu u lori ilẹ : iwọ kì yio sì fi i le ifẹ awọn ọtá rẹ lọwọ́.

3 Jehofa yio gbà a ni iyanju lori ẹní arun : iwọ o tẹ ẹní rẹ gbogbo ni ibulẹ arun rẹ.

4 Emi wipe, Jehofa, ṣãnu fu mi : mu ọkkàn mi lara da; nitori ti mo ti ṣẹ si ọ.

5 Awọn ọtá mi nsọ ibi si mi pe, Nigbawo ni on yio kú, ti orukọ rẹ yio sì run?

6 Bi o ba sì wá wò mi, on a ma sọ̀rọ asan : àiya rẹ kó èṣẹ jọ si ara rẹ ; nigbati o ba jade lọ, a ma wi i.

7 Gbogbo awọn ti o korira mi jùmọ nsọ̀rọ pelẹ si mi : emi ni nwọn ngbìmọ ibi mi si.

8 Nwọn nwipe, Arun buburu li o dì mọ́ ọ ṣinṣin : ati idubulẹ ti o dubulẹ yi, kì yio dide soke mọ́.

9 Nitõtọ ọrẹ́-iyọrẹ ara mi, ẹniti mo gbẹkẹle, ẹniti o jẹ ninu onjẹ mi, o sì gbé ara rẹ ga si mi.

10 Ṣugbọn iwọ, Jehofa, ṣãnu fu mi, ki o sì gbé mi dide, ki emi ki o le san a fu wọn.

11 Nipa eyi ni mo mọ̀ pe iwọ ṣe oju-rere si mi, nitori ti awọn ọtá mi kò yọ̀ mi.

12 Bi o sì ṣe ti emi ni, iwọ dì mi mu ninu ìwa-titọ mi, iwọ sì gbé mi kalẹ niwaju rẹ titi lai.

13 Olubukún ni Jehofa, Ọlọrun Israeli, lailai ati lailai Amin, Amin.

Digitized by Google

PSALMU 42.

BI agbọnrin ti ma mí-hẹlẹ si ipadò omi, Ọlọrun, bẽli ọkkàn mi nmí-hẹlẹ si ọ.

2 Ongbẹ Ọlọrun ngbẹ ọkkàn mi, ti Ọlọrun alãye : nigbawo li emi o wá, ti emi o sì yọ-ju niwaju Ọlọrun?

3 Omije mi li onjẹ mi li ọsán ati li oru, nigbati nwọn nwi fu mi nigba-gbogbo pe, Ọlọrun rẹ wà?

4 Nigbati mo ba ranti nkan wọnyi, emi tú ọkkàn mi jade ninu mi : nitori ti emi ti ba ỳpọ ijọ awọn enia lọ, emi ba wọn lọ si ile Ọlọrun, pẹlu ohùn ayọ̀ on iyìn, pẹlu ỳpọ awọn enia ti npa ọjọ mimọ́ mọ́.

5 Ẽṣe ti ori rẹ fi tẹ ba, iwọ ọkkàn mi? ẽṣe ti ara rẹ kò fi lelẹ ninu mi? iwọ ṣe ireti niti Ọlọrun : nitori ti emi o sá ma yìn i sibẹ, fu iranlọwọ oju rẹ.

6 Ọlọrun mi, ori ọkkàn mi tẹ ba ninu mi : nitori na li emi o ṣe ranti rẹ lati ilẹ Jordan wá, ati ti awọn ara Hermon, lati òke Misari wá.

7 Ibú omi npè ibú omi nipa hihó ṣiṣàn-omi : gbogbo riru-omi ati bibì-omi rẹ o bò mi mọlẹ.

8 Ṣugbọn JEHOFA yio paṣẹ iṣeun-ifẹ rẹ nigba ọsán, ati li oru orin rẹ yio wà pẹlu mi, ati adura mi si Ọlọrun emmí mi.

9 Emi o wi fu Ọlọrun apatta mi, Ẽṣe ti iwọ fi gbagbé mi? ẽṣe ti emi fi nrìn ni ìgbawẹ nitori inilara ọtá ni?

10 Bi ẹnipe pẹlu idà li egungun mi, awọn ọtá mi ngàn mi; nigbati nwọn nwi fu mi lojojumọ pe, Ọlọrun rẹ wà?

11 Ẽṣe ti ori rẹ fi tẹ ba, iwọ ọkkàn mi? ẽṣe ti ara rẹ kò sì fi lelẹ ninu mi? iwọ ṣe

Digitized by Google

ireti niti Ọlọrun : nitori ti emi o sá ma dupẹ fu u, ẹniti ṣe ilera oju mi, ati Ọlọrun mi.

Psalmu 43.

ṢE idajọ́ mi, Ọlọrun, ki o sì gbà ọ̀ran mi rò si alaìlãnu orilẹ ède : Gbà mi lọwọ́ ẹlẹtan ati ọkọnri alaìṣõtọ ni.

2 Nitori iwọ li Ọlọrun agbara mi : ẽṣe ti iwọ fi ṣa mi tì ? ẽṣe ti emi fi nrìn ni ìgbawẹ nitori inilara ọtá ni ?

3 Rán imọlẹ rẹ ati otitọ rẹ jade : ki nwọn ki o ma ṣe amọ̀na mi ; ki nwọn ki o mu mi gùn òke mimọ́ rẹ, ati sinu agọ́ rẹ wọn-ni.

4 Nigba na li emi o lọ si ibi pẹpẹ Ọlọrun, si Ọlọrun ayọ̀ nla mi : nitõto, lara dùru li emi o ma yìn ọ, Ọlọrun, Ọlọrun mi.

5 Ẽṣe ti ori rẹ fi tẹ̀ ba, iwọ ọkkàn mi ? ẽṣe ti ara rẹ kò sì fi lelẹ ninu mi ? iwọ ṣe ireti niti Ọlọrun : nitori ti emi o sá ma dupẹ fu u, ẹniti ṣe ilera oju mi, ati Ọlọrun mi.

OWURỌ̀ IJO. 9.

Psalmu 44.

ỌLỌRUN, awa ti fi etí wa gbọ́, awọn babba wa ti sọ fu wa, ni iṣẹ́ ti iwọ ṣe li ọjọ wọn, ni igba ọjọ-jọjọ.

2 Bi iwọ ti fi ọwọ́ rẹ lé awọn keferi jade, ti iwọ sì gbìn wọn ; bi iwọ ti foro awọn enia na, ti iwọ sì ṣa wọn tì.

3 Nitori ti nwọn kò ni ilẹ na nipa idà ti ara wọn, bẽni kì iṣe apa ara wọn li o gbà wọn là ; bikoṣe ọwọ́ ọtún rẹ, ati apa rẹ, ati imọlẹ oju rẹ, nitori ti iwọ ni ifẹ́ rere si wọn.

4 Iwọ li Ọbba mi, Ọlọrun : paṣẹ igbala fu Jakobu.

Digitized by Google

5 Nipasẹ rẹ li awa o bì awọn ọtá wa ṣubu : nipasẹ orukọ rẹ li awa o tẹ awọn ti ndide si wa mọlẹ.

6 Nitori ti emi kì yio gbẹkẹle ọrun mi, bẹ̃ni idà mi kì yio gbà mi là

7 Ṣugbọn bikoṣe iwọ li o ti ngbà wa là lọwọ awọn ọtá wa, iwọ sì ti dojutì awọn ti o korira wa.

8 Nipasẹ ti Ọlọrun li awa nṣe ileri li ọjọ gbogbo, awa sì nyìn orukọ rẹ lailai.

9 Ṣugbọn iwọ ti ṣa tì, iwọ sì ti dojutì wa; iwọ kò sì ba ogun wa jade lọ.

10 Iwọ mu wa pẹhinda si ọtá wa : ati awọn ti o korira wa nṣe ikogun fu ara wọn.

11 Iwọ ti fi wa fu jijẹ bi ẹran agutan; iwọ sì ti tú wa ká ninu awọn keferi.

12 Iwọ ti tà awọn enia rẹ li asan, iwọ kò sì fi wọn ṣọ ọrọ̀ rẹ di pupọ̀.

13 Iwọ ṣọ wa di ẹgan si awọn aladugbo wa, ẹlẹya ati iyọsuti si, si awọn ti o yi ni ká.

14 Iwọ ṣọ wa di ẹni owe ninu awọn keferi, ati imirisi ninu awọn enia.

15 Itiju mi mbẹ niwaju mi nigba-gbogbo, itiju mi sì bò mi mọlẹ.

16 Nitori ohùn ẹniti ngàn ti o sì nsọ̀rọ̀ buburu; nitori ipa ti ọtá ati olugbẹsan ni.

17 Gbogbo nwọnyi li o de si wa; ṣugbọn awa kò gbagbé rẹ, bẹ̃li awa kò ṣe eke ni majẹmu rẹ.

18 Àiya wa kò pada sẹhin, bẹ̃ni ìrin wa kò yà kuro ni ipa ti rẹ;

19 Bi iwọ tilẹ fọ́ wa bajẹ ni ibi awọn ejò, ti iwọ sì fi ojiji ikú bò wa mọlẹ.

20 Bi o ba ṣepe awa gbagbé orukọ Ọlọrun wa, tabi bi awa ba nà ọwọ́ wa si orisa kan;

21 Njẹ Ọlọrun kì yio ri idi rẹ̀? nitori ti o mọ̀ ohun ìkọkọ̀ àiya.

Digitized by Google

22 Nitõtọ, nitori rẹ li a ṣe npa wa kú li ọjọ gbogbo; a nkà wa bi agutan fu pipa.
23 Jí, ẽṣe ti iwọ nsùn, Oluwa? dide, má ṣe ṣa wa tì kuro lailai.
24 Ẽṣe ti iwọ fi pa oju rẹ mọ́, ti iwọ sì fi gbagbé ipọnju wa ati inira wa?
25 Nitori ti a tẹ̀ri ọkkàn wa balẹ si erupẹ̀: inu wa dì mọ́ erupẹ̀ ilẹ.
26 Dide fu iranlọwọ wa, ki o sì rà wa pada nitori ãnu rẹ.

Psalmu 45.

ÀIYA mi nhumọ̀ ọ̀ran rere: emi nsọ̀rọ ohun ti mo ti ṣe niti ọba: kalamu ayawọ iwe kikọ li ahọn mi.
2 Iwọ yanju jù awọn ọmmọ enia lọ: a dà ore-ọfẹ si ọ li ète: nitori na li Ọlọrun mbukún u fu ọ lailai.
3 Sán idà rẹ mọ́ idi rẹ, alagbara julọ, pẹlu ogo rẹ ati ọlá-nla rẹ.
4 Ati ninu ọlá-nla rẹ ma gẹṣin lọ li alafia, nitori otitọ ati ìwa-tutù ati ododo; ọwọ́ ọtun rẹ yio sì kọ́ ọ li ohun ẹ̀ru.
5 Ọfà rẹ mu li àiya awọn ọtá ọba; awọn enia nṣubu nisalẹ ẹṣẹ rẹ.
6 Ọlọrun, lailai ni itẹ́ rẹ: ọpá alade ti ijọba rẹ ọpá alade otitọ ni.
7 Iwọ fẹ ododo, iwọ korira ìwa-buburu: nitori na li Ọlọrun, Ọlọrun rẹ, ṣe fi àmi oróro ayọ̀ yà ọ ṣolori awọn ọ̀gba rẹ.
8 Gbogbo aṣọ rẹ li o nrùn turare, ati aloe, ati kasia, lati inu afin ehin jade, nibi ti nwọn gbé nmu ọ yọ̀.
9 Awọn ọmmọbiri ti awọn alade wà ninu awọn ọlọlá rẹ obiri: li ọwọ́ ọtún rẹ li ayabba na gbé duro ninu wura Ofiri.

Digitized by Google

10 Dẹti silẹ, ọmmọbiri, sì ronu, sì dẹ etí rẹ silẹ; gbagbé awọn enia rẹ pẹlu, ati ile babba rẹ;

11 Bẹ̃li ọbba yio fẹ ẹwà rẹ gidigidi: nitori on li Oluwa rẹ; ki iwọ o sì ma sìn i.

12 Ọmmọbiri Tire yio sì wà ibẹ ti on ti ọrẹ; ati awọn ọlọrọ ninu awọn enia yio ma bẹbẹ oju-rere rẹ.

13 Ti ogo ti ogo li ọmmọbiri alade na ninu: iṣẹ wura ọnà abẹrẹ li aṣọ rẹ.

14 Ninu aṣọ iṣẹ ọnà abẹrẹ li a o mu u tọ ọbba wá: awọn wundia ẹgbẹ rẹ ti ntọ ọ lẹhin li a o mu tọ ọ wá.

15 Pẹlu inu didùn ati pẹlu ayọ li a o fi mu wọn wá: nwọn o sì wọ afin ọbba lọ.

16 Nipo awọn babba rẹ li awọn ọmmọ rẹ yio wà, ẹniti iwọ o ma fi jẹ awọn alade lori ilẹ gbogbo.

17 Emi o ma ṣe orukọ rẹ ni iranti ni awọn iran gbogbo: nitorina li awọn enia yio ṣe ma yìn ọ lai ati lailai.

Psalmu 46.

OLỌRUN li àbo wa ati agbara, lọwọlọwọ iranlọwọ nigba ipọnju.

2 Nitorina li awa kì yio bẹ̀ru, bi a tilẹ ṣí ilẹ aiye ni idi, ti a sì rù awọn òke nla lọ si inu okun;

3 Bi omi rẹ tilẹ nhó ti o sì nru, bi awọn òke nla tilẹ nmì nipa ọwọ bibì rẹ.

4 Odò nla kan wà, omi ṣiṣàn eyiti yio mu inu ilu-nla Ọlọrun dùn, ibi mimọ́ ti agọ́ wọn-ni ti ọgá-ogo.

5 Ọlọrun mbẹ li arin rẹ; a kì yio ṣí i ni idi: Ọlọrun yio ràn a lọwọ́ ni kutukutu owurọ̀.

Digitized by Google

6 Awọn keferi nbinu, awọn ilẹ ọbba ṣídi : o fọhùn rẹ̀, ilẹ aiye yọ́.
7 JEHOFA awọn ọmmọ ogun wà pẹlu wa ; Ọlọrun Jakobu li àbo wa.
8 Ẹ wá wò awọn iṣẹ́ JEHOFA, irú ahoro ti o ṣe ni ilẹ aiye.
9 O mu ọ̀tẹ tan de opin ilẹ aiye ; o ṣẹ́ ọrun, o sì ke ọ̀kọ meji ; o fi kẹ̀kẹ́ ogun jona.
10 Ẹ duro jẹ, ki ẹ sì mọ̀ pe emi li Ọlọrun : a o gbé mi ga ninu awọn keferi, a o gbé mi ga li aiye.
11 JEHOFA awọn ọmmọ ogun wà pẹlu wa ; Ọlọrun Jakobu li àbo wa.

ALE IJỌ. 9.

PSALMU 47.

ENYIN gbogbo awọn enia, ẹ ṣapẹ ; ẹ fi ohùn iṣẹ́gun hó ihó iṣẹ́gun si Ọlọrun.
2 Nitori JEHOFA ọgá-ogo múna ; on li Ọbba nla lori ilẹ aiye gbogbo.
3 On ni yio ṣẹ́ awọn enia labbẹ wa, ati awọn orilẹ ède li atẹlẹsẹ wa.
4 On ni yio yàn ilẹ-ini wa fu wa, ọlọlá Jakobu ẹniti o fẹ.
5 Ọlọrun gòke lọ ti on ti ariwo, JEHOFA ti on ti iró ìpe.
6 Ẹ kọnrin iyìn si Ọlọrun, ẹ kọnrin iyìn : ẹ kọnrin iyìn si Ọbba wa, ẹ kọnrin iyìn.
7 Nitori Ọlọrun li Ọbba ti gbogbo ilẹ aiye : ẹ kọnrin iyìn gbogbo ẹniti o ni iyè.
8 Ọlọrun jọbba awọn keferi : Ọlọrun joko lori itẹ́ ìwa mimọ́ rẹ̀.
9 Awọn alade ti awọn enia kó ara wọn jọ, ani awọn enia ti Ọlọrun Abrahamu : nitori

Digitized by Google

asà ilẹ aiye ti Ọlọrun ni : on li a gbé leke jọjọ.

Psalmu 48.

ENI nla ni Jehofa, ti a yìn pupọ-pupọ ni ilu-nla ti Ọlọrun wa, li òke nla ìwa mimọ́ rẹ.

2 Didara ni ipò itẹdó, ayọ̀ ti gbogbo ilẹ aiye, li òke Sion, ni ìha ariwa, ni ilu ti Ọba nla.

3 A mọ̀ Ọlọrun li àbo ninu afin rẹ.

4 Sá wò o, awọn ọba pejọ pọ̀, nwọn jùmọ nkọja lọ.

5 Nwọn ri i, bẹ̃li ẹnu yà wọn; a yọ wọn lẹnu, nwọn yara lọ.

6 Ẹru bà wọn nibẹ̀, ati irora bi obiri ti nrọbi.

7 Iwọ fi ẹfufu ìla-õrùn fọ́ ọkọ̀ Tarṣiṣi.

8 Bi awa ti gbọ́, bẹ̃li awa ri ni ilu-nla ti Jehofa awọn ọmmọ ogun, ni ilu-nla ti Ọlọrun wa : Ọlọrun yio gbé e kalẹ lailai.

9 Awa ti nrò ti iṣeun-ifẹ rẹ, Ọlọrun, li arin tempeli rẹ.

10 Ọlọrun, gẹgẹ bi orukọ rẹ, bẹ̃ni iyìn rẹ de opin ilẹ aiye : ọwọ́ ọtún rẹ kún fu ododo.

11 Ki òke Sion ki o yọ̀, ki inu awọn ọmmọbiri Juda ki o dùn, nitori idajọ́ rẹ.

12 Rìn Sion kiri, ki o sì yi i ká : kà ileiṣọ rẹ.

13 Kiye si igbáti rẹ, kiye si afin rẹ wọn-ni ; ki ẹnyin le ma wi fu awọn iran atẹle nyin.

14 Nitori Ọlọrun yi Ọlọrun wa ni lai ati lailai : on ni yio ma ṣe amọ̀na wa titi ikú.

Psalmu 49.

EGBỌ́ eyi, gbogbo awọn enia; ẹ fi etí si i, gbogbo ẹnyin araiye:

Digitized by Google

2 Ati awọn ọmmọ ẹhin ati awọn ẹni ọllá, awọn ọlọrọ ati talakà pẹlu.
3 Ẹnu mi yio sọrọ ọgbọ́n, ati iṣaro àiya mi yio ṣe ti oyé.
4 Emi o dẹ etí mi silẹ si owe : emi o ṣí ọrọ ìkọkọ mi silẹ loju okùn dùru.
5 Ẽṣe ti emi o fi bẹ̀ru li ọjọ ibi, nigbati ẹ̀ṣẹ gigisẹ mi yio yi mi ká ?
6 Awọn ti o gbẹkẹle ọrọ̀ wọn, ti nwọn sì nṣe ileri li ọ̀pọ̀lọpọ ọrọ̀ wọn ;
7 Kò si ẹnikan ninu wọn bi o ti wù ki o ṣe ti o le rà arakọnri rẹ̀, bẽni kò le san owo irapada fu Ọlọrun nitori rẹ̀.
8 (Nitori irapada ọkkàn wọn iyebiye ni, o sì dakẹ lailai :)
9 Nipe ki o fi ma wà lailai, ki o má ṣe dibajẹ.
10 Nitori ti o nri pe awọn ọlọ́gbọn nkú, bẽli aṣiwere ati ẹranko enia nṣegbé, nwọn sì nfi ọrọ̀ wọn silẹ fu ẹlomiran.
11 Ìro inu wọn ni, ki ile wọn ki o pẹ titi lai, ati ibujoko wọn lati iran-diran ; nwọn sọ ilẹ wọn nipa orukọ ara wọn.
12 Ṣugbọn enia ti o wà ninu ọllá kò duro pẹ : o dabi ẹranko ti o ṣegbé.
13 Ipa ọ̀na wọn yi ni iwère wọn : ṣugbọn ọrọ wọn tọ́ li oju awọn ọmmọ wọn.
14 Bi agutan li a ntẹ́ wọn si isà okú ; ikú yio jẹun lara wọn ; ẹni diduro ṣinṣin ni yio jọ̀bba wọn li owurọ̀ ni ; ẹwà wọn yio sì tí ni isà okú kuro ni ibujoko wọn.
15 Ṣugbọn Ọlọrun ni yio rà ọkkàn mi lọwọ́ isà okú : nitori pe on ni yio gbà mi.
16 Iwọ má ṣe bẹ̀ru nigbati ẹnikan ba di ọlọrọ̀, nigbati iyìn ile rẹ̀ npọ̀ si i.
17 Nitori pe igbati o ba kú kì yio kó ohun kan lọ : ogo rẹ̀ kì yio sọkalẹ tọ̀ ọ lẹhin lọ.

Digitized by Google

18 Nigbati o wà lãye bi o tilẹ nsùre fu ọkkàn ara rẹ : awọn ẹnia yio yìn ọ, nigbati iwọ ba nṣe rere fu ara rẹ.
19 Ọkkàn yio lọ si ọdọ iran awọn babba rẹ ; nwọn kì yio ri imọlẹ lailai.
20. Ọkọnri ti o wà ninu ọllá, ti kò moye, o dabi ẹranko ti o ṣegbé.

OWURỌ IJỌ. 10.

Psalmu 50.

OLỌRUN olodumare, ani Jehofa li o ti sọrọ, o sì pè ilẹ aiye lati ìla-õrùn wá titi o fi de ìwọ rẹ na.
2 Lati Sion wá, pipé ẹwà, Ọlọrun ti ràn imọlẹ.
3 Ọlọrun wa mbọ, kì yio sì dakẹ : iná yio ma jó niwaju rẹ, yio sì ma jà ẹfufu lile yi i ká kiri.
4 Yio sì kọ si awọn ọrun lati oke wá, ati si ilẹ aiye, ki o le ma ṣe idajọ awọn enia rẹ.
5 Kó awọn enia mimọ́ mi jọ pọ̀ si ọdọ mi ; awọn ti o ti ba mi da majẹmu nipa ẹbọ.
6 Awọn ọrun yio sì sọrọ ododo rẹ : nitori Ọlọrun tikara rẹ li onidajọ.
7 Ẹ gbọ́, ẹnyin enia mi, emi o sì sọrọ ; Israeli, emi o sì jẽri si ọ : emi li Ọlọrun, ani Ọlọrun rẹ.
8 Emi kì yio ba ọ wi nitori ẹbọ rẹ tabi ọrẹ ẹbọ sisun rẹ, lati ma wà niwaju mi nigbagbogbo.
9 Emi kì yio mu akọ malu lati ile rẹ jade, tabi obukọ ninu awọn agbo ẹran rẹ :
10 Nitori gbogbo ẹran igbó ni ti emi, ati ẹran-kẹran lori ẹgbẹrun òke nla.

Digitized by Google

11 Emi mǫ̀ gbogbo awǫn ẹ̄iyẹ ti awǫn ɔ̀ke nla : ati ẹranko igbẹ́ ni ti emi.
12 Bi ebi npa mi, emi kì yio sǫ fu ǫ : nitori pe aiye ni ti emi, ati ẹkún inu rẹ̀.
13 Emi o ha jẹ ẹran malu, tabi emi a ma mu ẹ̀jẹ ewurẹ bi?
14 Ṣe ǫpẹ́ fu Ǫlǫrun, ki o sì san ileri ifẹ́ rẹ fu ǫgá-ogo :
15 Ki o sì kepè mi li ọjọ́ ipǫnju : emi o gbà ǫ, iwǫ o sì ma yìn mi logo.
16 Ṣugbǫn fu enia buburu Ǫlǫrun wipe, Kini iwǫ ni fi ṣe lati ma sǫ̀rǫ ofin mi, tabi ti iwǫ fi nmu majẹmu mi li ẹnu rẹ?
17 Wò o iwǫ sá korira ẹkọ́, iwǫ sì ti ṣa ǫ̀rǫ mi tì lẹhin rẹ.
18 Nigbati iwǫ ri olè, nigbana ni iwǫ ba a mǫ̀ ǫ pǫ̀, iwǫ sì ba awǫn àgbere ṣe ajǫpin.
19 Iwǫ fi ẹnu rẹ fu buburu, ati aha̱n rẹ npete ẹ̀tan.
20 Iwǫ joko iwǫ sì sǫ̀rǫ si arakǫnri rẹ : iwǫ mbà orukǫ ǫmmǫkǫnri iya ara rẹ jẹ.
21 Nkan nwǫnyi ni iwǫ ṣe, emi sì dakẹ; iwǫ ṣebi emi tilẹ dabi irú iwǫ tikara rẹ : ṣugbǫn emi o ba ǫ wi, emi o sì kà wǫn li ẹṣẹ-ẹṣẹ li oju rẹ.
22 Njẹ rò eyi, ẹnyin ti o gbagbé Ǫlǫrun, ki emi ki o má ba fà nyin ya pẹrẹ-pẹrẹ, ti kò si ẹniti yio ṣe atigbà.
23 Ẹnikẹni ti o ba bù iyìn, o yìn mi logo : ati ẹniti o ba mu ọ̀na ǫ̀rǫ rẹ̀ tǫ́ li emi o fi igbala Ǫlǫrun hàn fu.

Psalmu 51.

ǪLǪRUN, ṣãnu fu mi, gẹgẹ bi iṣeun-ifẹ́ rẹ : gẹgẹ bi irǫnu ǫ̀pǫ ãnu rẹ, nù irekǫja mi nù kuro.

Digitized by Google

2 Wẹ̀ mi li awẹmọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀ mi, ki o sì wẹ̀ mi nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀ mi.
3 Nitori ti mo jẹwọ irekọja mi : nigba-gbogbo li ẹ̀ṣẹ̀ mi sì mbẹ niwaju mi.
4 Iwọ, iwọ nikan-ṣoṣo ni mo ṣẹ̀ si, ti mo ṣe buburu yi niwaju rẹ : ki a le da ọ lare nigbati iwọ ba nsọ̀rọ, ki ara rẹ ki o le dá nigbati a ba mbá ọ wijọ.
5 Kiye si i, ninu ẹ̀ṣẹ̀ li a gbé ṣe ìwa mi ; ati ninu ẹ̀ṣẹ̀ ni iya mi sì lóyun mi.
6 Kiye si i, iwọ fẹ otitọ ni ipa inu : ati niha ìkọkọ ni iwọ o mu mi lati mọ̀ ọgbọ́n.
7 Fi eweko fọ̀ mi, emi o sì mọ́ : wẹ̀ mi, emi o sì fun jù omi didì lọ.
8 Mu mi gbọ́ ayọ̀ ati inu didùn ; ki awọn egungun ti iwọ ti run ki o le ma yọ̀.
9 Pa oju rẹ mọ́ kuro lara ẹ̀ṣẹ̀ mi, ki iwọ ki o sì nù gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ mi nù kuro.
10 Da àiya titun sinu mi, Ọlọrun ; ki o sì tún ọkkàn diduro ṣe sinu mi.
11 Má ṣe ṣa mi tì kuro niwaju rẹ ; ki o má sì ṣe gbà ẹmmí mimọ́ rẹ lọwọ́ mi.
12 Mu ayọ̀ igbala rẹ pada tọ̀ mi wá ; ki o sì fi ẹmmí rẹ omnira gbé mi duro.
13 Nigbana li emi o ma kọ́ awọn alarekọja li ọ̀na rẹ : awọn ẹlẹṣẹ yio sì ma yipada si ọ.
14 Ọlọrun, gbà mi lọwọ́ ẹ̀ṣẹ̀ mi ẹ̀jẹ, iwọ Ọlọrun igbala mi : ahọn mi yio sì ma kọnrin ododo rẹ soke.
15 Oluwa, iwọ ṣí mi li ète ; ẹnu mi yio sì ma fi iyìn rẹ hàn :
16 Nitori ti iwọ kò fẹ ẹbọ ; ti emi iba ru u : inu rẹ kò dùn si ọrẹ ẹbọ sisun.
17 Ẹbọ Ọlọrun ni irobinujẹ ọkkàn : irobinujẹ ati irora àiya, Ọlọrun, on ni iwọ kì yio gàn.

Digitized by Google

18 Ṣe rere ninu didùn inu rẹ si Sion : iwọ mọ odi Jerusalemu.
19 Nigbana ni inu rẹ yio dùn si ẹbọ ododo, pẹlu ọrẹ ẹbọ sisun ati ọtọtọ ọrẹ ẹbọ ṣisun : nigbana ni nwọn o fi akọ malu rubọ lori pepele rẹ.

Psalmu 52.

ẼṢE ti iwọ fi nṣe-fefe ninu ìwa ìka, iwọ alagbara ọkọnri? ore Ọlọrun duro pẹ titi.
2 Ahọn rẹ ngbìro ìwa ìka; bi abẹ mimu, o nṣiṣẹ ẹ̀tan.
3 Iwọ fẹ ibi jù ire lọ; ati eke jù ati sọ ododo lọ.
4 Iwọ fẹ ọ̀rọ ipanirun gbogbo, iwọ ahọn ẹ̀tan.
5 Ọlọrun yio sì lù ọ bolẹ lailai, yio sì mu ọ kuro, yio sì já ọ kuro ni ibujoko rẹ, yio sì fà ọ tú kuro lori ilẹ ti awọn alãye.
6 Olododo yio ri i pẹlu, yio sì bẹ̀ru, yio sì ma rẹrin rẹ : pe,
7 Kiye si i, ọkọnri ti kò fi Ọlọrun ṣe agbara rẹ̀ li eyi, bikoṣe li ọ̀pọlọpọ ọrọ̀ rẹ̀ li o gbẹ́kẹle, o sì mu ara rẹ̀ le ninu ohun ìwa-buburu rẹ̀.
8 Ṣugbọn emi dabi igi olifi tutù ni ile Ọlọrun : emi gbẹ́kẹle ãnu Ọlọrun lai ati lailai.
9 Emi o ma yìn ọ lailai, nitori pe iwọ li o ṣe e : emi o sì ma duro tì orukọ rẹ; nitori ti o dara li oju awọn enia mimọ́ rẹ.

ALẸ IJỌ. 10.

Psalmu 53.

ENIA buburu wi li ọkàn rẹ̀ pe, Ọlọrun kò sì. Nwọn bajẹ, nwọn sì nṣe irira ẹ̀ṣẹ : kò si ẹni ti o ṣe rere.

Digitized by Google

2 Ọlọrun bojuwò ilẹ lati ọrun wá sara awọn ọmmọ enia, lati wò bi ẹnikan wà ti oyé yé, ti o sì nwá Ọlọrun.

3 Gbogbo wọn li o sì pada sẹhin : nwọn sì di elẽri patapata; kò si ẹni ti nṣe rere, kò si ẹnikan.

4 Awọn ti nṣiṣẹ ẹṣẹ kò ni ìmọ? awọn ẹniti njẹ enia mi bi ẹni jẹun : nwọn kò si kepè Ọlọrun.

5 Nibẹ ni nwọn gbé wà ni ìbẹru nla, nibiti ẹ̀ru kò gbé si : nitori ti Ọlọrun ti fọn egungun awọn ti o dó tì ọ ká : iwọ ti dojutì wọn, nitori Ọlọrun ti kẹgàn wọn.

6 Tani yio fi igbala fu Israeli lati Sion jade wá! Nigbati Ọlọrun ba mu ikolọ ogun awọn enia rẹ pada wá, Jakobu yio yọ, inu Israeli yio sì dùn.

Psalmu 54.

OLỌRUN, gbà mi là nipa orukọ rẹ, sì ṣe idajọ mi nipa agbara rẹ.

2 Gbọ́ adura mi, Ọlọrun; fi etí si ọ̀rọ ẹnu mi.

3 Nitori ti awọn alejò dide si mi, awọn aninilara sì nwá ọkkàn mi : nwọn kò kà Ọlọrun si li oju wọn.

4 Kiye si i, Ọlọrun li oluranlọwọ mi : Oluwa wà pẹlu awọn ti o gbé ọkkàn mi duro.

5 Yio sì fi ibi san a fu awọn ọtá mi : ke wọn kuro ninu otitọ rẹ.

6 Emi o fi ifarabalẹ rubọ si ọ : Jehofa, emi o yìn orukọ rẹ; nitori ti o dara.

7 Nitori ti o ti yọ mi kuro ninu ìṣẹ́ gbogbo : oju mi sì ri ifẹ́ mi lara awọn ọtá mi.

Digitized by Google

Psalmu 55.

FI etí si adura mi, Ọlọrun; má sì ṣe fi ara rẹ pamọ́ kuro ninu ẹbẹ mi.

2 Fiye si mi, ki o sì gbohùn mi: emi nṣòfọ ninu aroye mi, emi sì npariwo;

3 Nitori ohùn ti ọtá ni, nitori inilara ti enia buburu: nitori ti nwọn nta ẹṣẹ si mi lara, ati ni ibinu nwọn korira mi.

4 Àiya ndùn mi gidigidi ninu mi: ipaiya ikú sì ṣubu lù mi.

5 Ìbẹru ati iwa-rìri wá si ara mi, ati ìbẹru ikú bò mi mọlẹ.

6 Emi sì wipe, Ã, iba ṣe pe emi ni iyẹ apa bi àdaba! emi iba fò lọ, emi a sì simi.

7 Kiye si i, emi iba rìn lọ li ọna jijin rere, emi a sì ma gbé li aginjù.

8 Emi iba yara sá asala mi kuro ninu afẹfẹ ati ìji ẹfufu na.

9 Oluwa, se iparun, ki o sì yà wọn li ahọn: nitori ti mo ri ìwa agbara ati ìja ni ilu-nla na.

10 Ọsán ati oru ni nwọn fi nrìn odi rẹ̀ kiri: ìwa ìka pẹlu ati ikãnu mbẹ li arin rẹ̀.

11 Ìwa-buburu mbẹ li arin rẹ̀: ẹ̀tan ati eke kò lọ kuro ni igboro rẹ̀.

12 Nitori ti kì iṣe ọtá li o gàn mi; njẹ emi iba pa a mọra: bẽni kì iṣe ẹniti o korira mi li o gbé ara rẹ̀ ga si mi; njẹ emi iba fi ara mi pamọ́ kuro lọdọ rẹ̀:

13 Ṣugbọn iwọ ni, ọkọnri ọgba mi, amọ̀na mi, ati ojulumọ̀ mi.

14 Awa jùmọ gbìmọ didùn, awa sì kẹgbẹ rìn wọ̀ ile Ọlọrun lọ.

15 Ki ikú ki o dì wọn mu, ki nwọn ki o sì lọ lãye si isà okú: nitori ti ìwa-buburu mbẹ ni ibujoko wọn, ati ninu wọn.

Digitized by Google

16 Bi o ṣe ti emi ni, emi o kepè Ọlọrun; JEHOFA yio sì gbà mi là.

17 Li alẹ, li owurọ, ati li ọsán, li emi o ma gbadura, ti emi o sì ma kigbe kunkun : on yio sì gbohùn mi.

18 O ti gbà ọkkàn mi là li alafia lọwọ ogun ti o ti dó tì mi : nitori pe ọpọlọpọ enia li o pẹlu mi.

19 Ọlọrun yio gbọ, yio sì pọn wọn loju, ani ẹni atijọ ni ti o ti joko. Nitori ti kò si ayidà, nitori na nwọn kò bẹru Ọlọrun.

20 O ti nà ọwọ rẹ si irú awọn ti o wà li alafia pẹlu rẹ : o ti ṣe ọdalẹ majẹmu rẹ.

21 Ọrọ ẹnu rẹ kun-na jù ori-amọ lọ, ṣugbọn ìja li o wà li àiya rẹ : ọrọ rẹ kun-na jù oróro lọ, ṣugbọn idà fifayọ ni nwọn.

22 Kó ẹrù rẹ lọ si ara JEHOFA, on ni yio sì mu ọ duro : on kì yio jẹ ki ẹsẹ olododo ki o yẹ lai.

23 Ṣugbọn iwọ, Ọlọrun, ni yio mu wọn sọkalẹ lọ si ihò iparun : awọn enia ẹjẹ ati enia ẹtan kì yio pẹ àbọ ọjọ wọn; ṣugbọn emi o gbẹkẹle o.

OWURỌ IJỌ. 11.

PSALMU 56.

OLỌRUN, ṣãnu fu mi : nitori ti enia nfẹ gbé mi mì; o mbá mi jà lojojumọ o n-ni mi lara.

2 Awọn ọtá mi nfẹ gbé mi mì lojojumọ : nitori ti awọn ti mbá mi jà pọ, iwọ ọgá-ogo.

3 Nigbati ẹru ba mbà mi, emi o gbẹkẹle o.

4 Nipa Ọlọrun li emi o ma yìn ọrọ rẹ, Ọlọrun li emi gbẹkẹ mi le; emi kì yio bẹru ohun ti enia le ṣe si mi.

Digitized by Google

5 Lojojumọ ni nwọn nlọ ọrọ mi : ibi ni gbogbo ìro inu wọn si mi.
6 Nwọn kó ara wọn jọ, nwọn fi ara wọn pamọ, nwọn nkiye si ìrin mi, nigbati nwọn nṣọna ọkkàn mi.
7 Nwọn le ti ipa èṣẹ là a? ni ibinu rẹ wọ́ wọn já ti ilẹ, Ọlọrun.
8 Iwọ nkà ìrin-kiri mi : fi omije mi sinu ọpalaba rẹ : nwọn kò ha si ninu iwe rẹ bi?
9 Nigbati mo ba kigbe pè ọ, nigbana li awọn ọtá mi yio pẹhinda : eyi li emi mọ; nitori pe Ọlọrun wà fu mi.
10 Nipa Ọlọrun li emi o ma yìn ọrọ rẹ̀ : nipa JEHOFA li emi o ma yìn ọrọ rẹ̀.
11 Ọlọrun li emi gbẹkẹ mi le : emi kì yio bẹ̀ru ohun ti enia le ṣe si mi.
12 Ileri ifẹ́ rẹ mbẹ lara mi, Ọlọrun : emi o fi iyìn-iyin fu ọ.
13 Nitori pe, iwọ li o ti gbà ọkkàn mi lọwọ́ ikú : iwọ kì yio gbà ẹsẹ mi lọwọ́ iṣubu, ki emi ki o le ma rìn niwaju Ọlọrun ni imọlẹ awọn alãye?

PSALMU 57.

SÃNU fu mi, Ọlọrun, ṣãnu fu mi : nitori ti ọkkàn mi gbẹkẹle ọ : lõtọ, li ojiji iyẹ́ apa rẹ li emi o fi ṣe àbo mi, titi wahalà nwọnyi yio fi rekọja.
2 Emi o kigbe pè Ọlọrun ọgá-ogo; si Ọlọrun ti o ṣe ohun gbogbo fu mi.
3 On yio ranṣẹ lati ọrun wá, yio sì gbà mi lọwọ́ ègan awọn ti nfẹ gbé mi mì. Ọlọrun yio rán ãnu rẹ̀ ati otitọ rẹ̀ jade.
4 Ọkkàn mi wà larin awọn kiniu : emi tilẹ dubulẹ larin awọn ti o gbiná, eyini ni awọn

Digitized by Google

ọmmọ enia, ehin ẹniti ṣe ọ̀kọ ati ọfà, ati ahọn wọn idà mimu.

5 Gbígbe-ga ni iwọ, Ọlọrun, jù awọn ọrun lọ; ati ogo rẹ jù gbogbo ilẹ aiye lọ.

6 Nwọn ti ta àwọn silẹ fu ẹsẹ mi; ori ọkkàn mi tẹ̀ ba: nwọn ti wà ihò kan silẹ niwaju mi, larin eyi na li awọn tikara wọn jìn si.

7 Ọkkàn mi ti mura, Ọlọrun, ọkkàn mi ti mura: emi o kọnrin, emi o sì ma fi iyìn.

8 Jí, iwọ ogo mi; jí, èlo orin mimọ́ ati dùru: emi tikara mi yio sì jí ni kutukutu.

9 Emi o ma yìn ọ, OLUWA, ninu awọn enia: emi o sì ma kọnrin si ọ ninu awọn orilẹ ède.

10 Nitori ti ãnu rẹ pọ̀ de awọn ọrun, ati otitọ rẹ de awọn awọ̀-sanma.

11 Gbígbe-ga ni iwọ, Ọlọrun, jù awọn ọrun lọ; ati ogo rẹ jù gbogbo ilẹ aiye lọ.

PSALMU 58.

ENYIN nsọ ododo nitõtọ, ẹnyin ijọ awọn enia? ẹnyin nṣe idajọ́ ti o ṣe títọ, ẹnyin ọmmọ enia?

2 Nitõtọ, ẹnyin nṣiṣẹ buburu li àiya; ẹnyin nwọ̀n lwa agbara ti ọwọ́ nyin li aiye.

3 Lati inu wá li awọn enia buburu ti ṣe iyapa: nwọn ti ṣìna lojukan na ti a ti bí wọn, nwọn a ma ṣeke.

4 Oró wọn dabi oró ejò: nwọn dabi aditi ejò pamọlẹ ti o di ara rẹ̀ li etí;

5 Ti kò fẹ gbọ́ ohùn awọn atuniloju, bi o ti wù ki o ma fi ọgbọ́n ṣe ituju to.

6 Ká wọn li ehin, Ọlọrun, li ẹnu wọn: ká ehin nla ti awọn ọmmọ kiniu ni, JEHOFA.

7 Ki nwọn ki o yọ́ dànu bi omi ti nṣàn

Digitized by Google

nigba-gbogbo : nigbati o ba fà ọrun rẹ̀ le lati tafà rẹ̀, ki nwọn ki o dabi ẹni ke wọn ni ijanja.

8 Bi igbin ti nyọ́ dànu, jẹ ki olukuluku wọn ki o ma fò lọ : bi iṣẹnu obiri, ki nwọn ki o má ṣe ri õrùn.

9 Ki ìkoko nyin ki o to mọ̀ igbona ẹgún, yio mu wọn kuro bi ẹnipe lati ọwọ́ ìji wa, ati alãye ati ni ibinu rẹ̀.

10 Olododo yio yọ̀ nigbati o ba ri ẹsan na : yio sì wẹ̀ ẹsẹ̀ rẹ̀ ninu ẹ̀jẹ̀ ti awọn enia buburu.

11 Bẹ̃li enia o sì wipe, Lõtọ̀ ère mbẹ fu olododo : lõtọ̀, on li Ọlọrun ti o nṣe idajọ́ ni ilẹ̀ aiye.

ALẸ IJỌ. 11.

PSALMU 59.

OLỌRUN mi, gbà mi lọwọ́ awọn ọtá mi : dãbobo mi lọwọ́ awọn ti o dide si mi.

2 Gbà mi lọwọ́ awọn oniṣẹ̀ ẹ̀ṣẹ̀, ki o sì gbà mi là lọwọ́ awọn enia ẹ̀jẹ̀.

3 Sá kiye si i, nwọn ba ni buba fu ọkkàn mi : awọn alagbara pejọ si mi ; kì iṣe nitori irekọja mi, tabi nitori ẹ̀ṣẹ̀ mi, JEHOFA.

4 Nwọn súre, nwọn mura li alẹ̀ṣẹ̀ mi : dide lati pade mi, ki o sì kiye si i.

5 Nitori na iwọ, JEHOFA, Ọlọrun awọn ọmmọ-ogun, Ọlọrun Israeli, jí lati bẹ̀ gbogbo awọn keferi wò : má ṣe ṣãnu fu ẹni buburu olurekọja wọn-ni.

6 Nwọn pada li aṣalẹ : nwọn npariwo bi ajá, nwọn nrìn yi ilu-nla na ká.

7 Kiye si i, nwọn nfi ẹnu wọn gùfẹ jade : idà wà li ète wọn : nitori ti nwọn nwipe, tali o gbọ́ ?

Digitized by Google

8 Ṣugbọn iwọ, JEHOFA, ni yio rẹrin wọn; iwọ ni yio yọsùti si gbogbo awọn keferi.

9 Nitori agbara rẹ li emi o ṣe duro tì ọ: nitori Ọlọrun li àbo mi.

10 Ọlọrun ãnu mi ni yio ṣaju mi: Ọlọrun yio jẹ ki emi ri ifẹ mi lara awọn ọtá mi.

11 Má ṣe pa wọn, ki awọn enia mi ki o má ba gbagbé: tú wọn ká nipa agbara rẹ; ki o sì sọ wọn kalẹ, OLUWA asà wa.

12 Nitori ẹ̀ṣẹ ẹnu wọn, ati ọ̀rọ ète wọn, ki a mu wọn nipa igberaga wọn: ati nitori ebú ati eke ti nwọn nṣe.

13 Run wọn ni ibinu, run wọn, ki nwọn ki o má ṣe si mọ́: ki o sì jẹ ki nwọn ki o mọ̀ pe, Ọlọrun li olori ni Jakobu titi o fi de opin ilẹ aiye.

14 Ati li aṣalẹ jẹ ki nwọn ki o pada; ki nwọn ki o pariwo bi ajá, ki nwọn ki o sì ma yi ilu-nla na ká kiri.

15 Jẹ ki nwọn ki o ma rìn soke rìn sodò fu ohun jijẹ, bi nwọn kò ba yó njẹ nwọn o duro li alẹ na gbogbo.

16 Ṣugbọn emi o kọnrin agbara rẹ; nitõtọ, emi o kọnrin ãnu rẹ kunkun li owurọ̀: nitori pe iwọ li o ti nṣe àbo ati asala mi li ọjọ ipọnju mi.

17 Iwọ agbara mi li emi o kọnrin si: nitori Ọlọrun li àbo mi, ati Ọlọrun ãnu mi.

PSALMU 60.

OLỌRUN, iwọ ti ṣa wa tì, iwọ ti tú wa ká, inu rẹ ti bajẹ; tún ara rẹ yipada si wa.

2 Iwọ ti mu ilẹ wa-rìri; iwọ ti fọ ọ: mu ọgbẹ rẹ jina; nitori ti o nmì.

3 Iwọ ti fi ohun ti o ṣoro hàn awọn enia rẹ: iwọ ti mu wa mọti wain iyanu.

Digitized by Google

4 Iwọ ti fi ọpágun fu awọn ti o bẹ̀ru rẹ, ki a le ma fi i hàn nitori otitọ.
5 Ki a le gbà olufẹ rẹ là; fi ọwọ́ ọtún rẹ ṣe igbala, ki o sì gbohùn mi.
6 Ọlọrun ti sọ̀rọ ninu ìwa mimọ́ rẹ̀ pe; Emi o yọ̀, emi o pín Ṣekemu, emi o sì wọ̀n afonifoji Sukotu.
7 Ti emi ni Gileadi, ti emi ni Manase; Efraimu pẹlu li agbara ori mi; Juda li olofin mi;
8 Moabu li afọ̀koko mi; lori Edomu li emi o bọ́ bàta mi si: iwọ Filistia ma yọ̀ lori mi.
9 Tani yio mu mi wá sinu ilu-nla alagbara ni? tani yio sìn mi lọ si Edomu?
10 Iwọ kọ́, Ọlọrun, ẹniti o ṣa wa tì? ati iwọ, Ọlọrun, ti kò ti bá awọn ogun wa jade lọ?
11 Fu wa ni iranlọwọ ninu ipọnju: nitori pe asan ni iranlọwọ enia.
12 Nipasẹ ti Ọlọrun li awa o ṣe iṣe agbara: nitori on ni yio tẹ̀ awọn ọtá wa mọlẹ.

Psalmu 61.

GBỌ́ ẹkún mi, Ọlọrun; fiye si adura mi.
2 Lati opin ilẹ aiye wá li emi o kigbe pè ọ, nigbati àiya mi bò mi mọlẹ: fà mi lọ si apatta ti o ga jù mi lọ.
3 Nitori iwọ li o ti nṣe àbo fu mi, ati ilẹ-iṣọ agbara lọwọ́ ọtá ni.
4 Emi o joko ninu agọ́ rẹ lailai: emi o ma gbẹ̀kẹle àbo iyẹ́ apa rẹ.
5 Nitori pe iwọ, Ọlọrun, li o ti gbọ́ ileri ifẹ́ mi: iwọ ti fi ogún awọn ti o bẹ̀ru orukọ rẹ fu mi.
6 Iwọ o fà ẹmmí ọbba gùn: ati ọjọ ọdún rẹ̀ bi atiran-diran.

Digitized by Google

7 On yio ma gbé iwaju Ọlọrun lailai; pèse ãnu ati otitọ, ti yio ma ṣe itọju rẹ.
8 Bẹ̃li emi o ma kọnrin iyìn si orukọ rẹ lailai, ki emi ki o le ma san ileri ifẹ mi li ojojumọ.

OWURỌ IJỌ. 12.

Psalmu 62.

NITỌ̃TỌ li ọkkàn mi duro tì Ọlọrun: lati ọdọ rẹ wá ni igbala mi.
2 On nikan li apatta mi ati igbala mi; on li àbo mi; emi kì yio ṣipò pada jọjọ.
3 Ẹnyin o ti ma gbìro ìwa-buburu si enia kan pẹ to? gbogbo nyin li a o pa: bi àbati àlapa li ẹnyin o rì, ati bi ọgbà ti nwó lọ.
4 Kìki ìro wọn ni bi nwọn o ti já a ti ilẹ kuro ninu ọllá rẹ: nwọn nṣe inu didùn ninu eke: nwọn nfi ẹnu wọn sùre, ṣugbọn nwọn ngegun niha inu wọn.
5 Ọkkàn mi, iwọ sá duro tì Ọlọrun; nitori lati ọdọ rẹ wá ni ireti mi.
6 On nikan li apatta mi ati igbala mi: on li àbo mi; a kì yio ṣí mi ni ipò.
7 Nipa Ọlọrun ni igbala mi, ati ogo mi: apatta agbara mi, àbo mi sì mbẹ nipa Ọlọrun.
8 Gbẹkẹle e nigba-gbogbo; ẹnyin awọn enia, tú ọkkàn nyin jade niwaju rẹ: Ọlọrun li àbo fu wa.
9 Nitõtọ asan li awọn enia ọmmọ ẹhin, ati awọn enia eke li awọn oloyè: lati ṣìwọn wọn ninu ðṣuwọn, bakan na ni nwọn fẹrẹ jù asan lọ.
10 Má ṣe gbẹkẹle inilara, ki o má sì ṣe gbe-

Digitized by Google

raga li olè jija : bi ọrọ̀ ba npọ̀ si i, má ṣe gbé ọkkàn nyin le e.

11 Ọlọrun ti sọ̀rọ̀ lẹ̀kan; ẹrinkeji ni mo gbọ́ eyi; pe ti Ọlọrun li agbara.

12 Pẹlu-pẹlu, Oluwa, iwọ li alãnu : nitori ti iwọ san a fu olukuluku enia gẹgẹ bi iṣe rẹ̀.

Psalmu 63.

JEHOFA, iwọ li Ọlọrun mi; ni kutukutu li emi o ma ṣafẹri rẹ : ongbẹ rẹ ngbẹ ọkkàn mi, ẹran ara mi fà si ọ ni ilẹ gbigbẹ ati ilẹ ti npè ongbẹ, nibiti omi kò gbé si;

2 Lati ri agbara rẹ ati ogo rẹ, bẹ̃li o dabi ẹnipe mo ti ri ọ ninu ibi mimọ́.

3 Nitori ti iṣeun-ifẹ́ rẹ sanju ìye lọ, ète mi yio ma yìn ọ.

4 Bayi li emi o ma fi ibukun fu ọ niwọn bi mo ti wà lãye : emi o ma gbé ọwọ́ mi soke nipa orukọ rẹ.

5 Bi ẹnipe ọrá bẹ̃ni yio tẹ́ ọkkàn mi lọrùn; ẹnu mi yio sì ma fi ète ayọ̀ yìn ọ :

6 Nigbati mo ba ranti rẹ lori ẹní mi, ti emi sì nṣe aṣaro rẹ ni iṣọ́ oru.

7 Nitori pe iwọ li o ti nṣe oluranlọwọ mi, nitorina li ojiji iyẹ́ apa rẹ li emi o ma yọ̀.

8 Ọkkàn mi ntọ̀ ọ lẹhin girigiri : ọwọ́ ọtún rẹ li o gbé mi ró.

9 Ṣugbọn awọn ti nwá ọkkàn mi, lati pa a run, nwọn o lọ si ìha isalẹ ilẹ.

10 Nwọn o ti ọwọ́ idà ṣàn lọ bi omi : nwọn o sì ṣe ijẹ fu kọ̀lọ̀kọlọ.

11 Ṣugbọn ọbba yio ma yọ̀ nipa Ọlọrun; olukuluku ẹniti o nfi i bura ni yio ṣogo : ṣugbọn ẹnu awọn ti nṣeke li a o pa li ẹnu mọ́.

Digitized by Google

PSALMU 64.

OLỌRUN, gbohùn mi, ninu adura mi : pa ẹmmí mi mọ́ lọwọ́ ẹ̀ru ọtá ni.

2 Pa mi mọ́ lọwọ́ ìmọ ìkọkọ ti awọn enia buburu; lọwọ́ irukerudo ti awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ.

3 Ẹniti npọ́n ahọn wọn bi ẹnipe idà, ti nwọn sì fà ọrun wọn le lati tafà wọn, ani ọ̀rọ kikorò :

4 Ki nwọn ki o le ma tafà ni ìkọkọ si awọn ti o pé : lojijì ni nwọn ntafà si i, nwọn kò sì bẹ̀ru.

5 Nwọn ngbà ara wọn niyanju li ọ̀rọ buburu : nwọn ngbìmọ ati dẹkun silẹ nikọ̀kọ; nwọn nwipe, Tani yio ri wọn?

6 Nwọn nwadi ẹ̀ṣẹ; nwọn ṣe awá tan : ati ìro inu olukuluku wọn, ati àiya wọn o jinlẹ.

7 Ṣugbọn Ọlọrun yio tafà kan si wọn; lojijì ni nwọn o gbọgbẹ.

8 Bẹ̃ni nwọn o mu ahọn ara wọn ṣubu lù ara wọn : gbogbo ẹniti o ri wọn yio sá lọ.

9 Ati gbogbo awọn enia ni yio ma bẹ̀ru, nwọn o sì ma sọ̀rọ iṣẹ́ Ọlọrun; nitori ti nwọn o fi ọgbọ́n rò iṣẹ́ rẹ̀.

10 Olododo yio ma yọ̀ nipa ti JEHOFA, yio sì ma gbẹkẹle e; ati gbogbo awọn ẹni iduro ṣinṣin li àiya ni yio ma ṣogo.

ALẸ IJỌ. 12.

PSALMU 65.

OLỌRUN, iyìn duro dè ọ ni Sion : ati si ọ li a o sì mu ileri iṣẹ́ ni ṣẹ.

2 Iwọ ti ngbọ́ adura, si ọdọ rẹ ni gbogbo awọn enia mbọ̀.

Digitized by Google

3 Ẹ̀ṣẹ bori mi : bi o ṣe ti irekọja mi ni, iwọ ni yio wẹ̀ wọn nù kuro.

4 Alabukún-fu li ẹniti iwọ yàn, ti iwọ sì mu lati ma sumọ́ ọdọ rẹ, ki o le ma gbé inu agọ́ rẹ wọn-ni : ore inu ile rẹ yio tẹ́ wa lọrùn, ani ti inu tempeli mimọ́ rẹ.

5 Ohun ẹ̀ru nipa ododo ni iwọ o fi da wa lohùn, Ọlọrun igbala wa ; ẹniti ṣe igbẹkẹle ti gbogbo opin ilẹ aiye, ati ti awọn ti o jina rere li oju okun :

6 Nipa agbara rẹ ẹniti o fi idi òke nla mulẹ ṣinṣin ; ti a fi agbara dì li amure :

7 Ẹniti o pa ariwo okun mọ́ rọrọ, ariwo riru omi wọn, ati gidigidi awọn enia.

8 Awọn pẹlu ti ngbé apa ipẹkun mbẹ̀ru nipa àmi rẹ wọn-ni : iwọ mu ijade ti owurọ̀ ati ti aṣalẹ yọ̀.

9 Iwọ bẹ̀ ilẹ aiye wò, o sì bomi rin i : iwọ fi odò nla Ọlọrun ti o kún fu omi ṣe ọrọ̀ rẹ̀ : iwọ pèse ọkà wọn nigbati iwọ ti pèse fu u bẹ̃.

10 Iwọ fi irinmi si ori ata rẹ̀ gidigidi : iwọ sì ti ṣàn omi si aporo rẹ̀ : iwọ fi ọwọ̀ ọjo mu ilẹ rẹ̀ rọ̀ : iwọ busi eso rẹ̀.

11 Iwọ fi ore rẹ de ọdún li ade ; ọrá nkán nipa ọ̀na rẹ.

12 Nwọn nkán si ori papa tutù ti aginjù : awọn òke kekere nyọ̀ ni ìha gbogbo.

13 Agbo ẹran li o wọ̀ papa tutù na li aṣọ ; afonifoji li o bò mọlẹ fu ọkà ; nwọn nhó fu ayọ̀, nwọn nkọnrin pẹlu.

Psalmu 66.

EHÓ ihó ayọ̀ si Ọlọrun, ẹnyin ilẹ gbogbo : 2 Ẹ kọnrin ọlá ti orukọ rẹ̀ jade ; ẹ mu iyin rẹ̀ li ogo.

3 Ẹ wi fu Ọlọrun pe, Iwọ ti li ẹ̀ru to ninu

Digitized by Google

iṣ́ẹ́ rẹ̀! nipa ọ̀pọ̀ agbara rẹ̀ li awọn ọ̀tá rẹ̀ yio fi ori wọn balẹ̀ fu ọ.

4 Gbogbo aiye ni yio ma sìn ọ, ti nwọn o sì ma kọnrin si ọ; nwọn o ma kọnrin si orukọ rẹ̀.

5 Ẹ wá wò iṣ́ẹ́ Ọlọrun: o li ẹ̀ru ni iṣe rẹ̀ si awọn ọmmọ enia.

6 O sọ okun di ilẹ̀ gbigbẹ̀: nwọ́ nlà inu ìṣanomi já li ẹsẹ̀: nibẹ̀ li awa gbé yọ̀ nipa ti rẹ̀.

7 O ṣe olori nipa agbara rẹ̀ lailai; oju rẹ̀ nwò awọn orilẹ̀ ède: má ṣe jẹ̀ ki awọn ọlọ̀tẹ̀ ki o gbé ara wọn ga.

8 Ẹ fi ibukún fu Ọlọrun wa, ẹnyin enia, ki ẹ sì mu ni gbọ́ ohùn iyìn rẹ̀.

9 Ẹniti o mu ẹmmí wa wà lãye, ti kò sì jẹ̀ ki ẹsẹ̀ wa ki o yẹ̀.

10 Ọlọrun, nitori ti iwọ ti ri idi wa: iwọ ti dan wa wò, bi a ti dan fadaka wò.

11 Iwọ mu wa wọ̀ inu àwọn; iwọ fi ipọnju le wa li ẹgbẹ́.

12 Iwọ mu awọn enia gùn wa li ẹṣin li ori; awa là inu iná ati inu omi já lọ: ṣugbọ̀n iwọ mu wa jade wá si ibi ọrọ̀.

13 Emi o lọ sinu ile rẹ̀ ti emi ti ọrẹ ẹbọ sisun: emi o san ileri iṣẹ́ mi fu ọ,

14 Ti ète mi ti ṣe, ti ẹnu mi sì ti sọ, nigbati mo wà ninu ipọnju.

15 Emi o ru ẹbọ sisun ọlọrá si ọ, pẹlu turare àgbo; emi o rubọ akọ malu pẹlu ewurẹ.

16 Ẹ wá gbọ́, gbogbo ẹnyin ti o bẹ̀ru Ọlọrun, emi o sọ ohun ti o ṣe fu ọkkàn mi.

17 Emi fi ẹnu mi kigbe pè e, emi sì fi ahọn mi buyìn rẹ̀.

18 Emi iba gbà ẹ̀ṣẹ̀ li àiya mi, Oluwa kì ba ti gbohùn mi:

Digitized by Google

19 Ṣugbọn nitõtọ Ọlọrun ti gbohùn mi; o sì ti fi etí si ohùn adura mi.
20 Olubukún li Ọlọrun, ti kò yi adura mi pada kuro, tabi ãnu rẹ̀ kuro lọdọ mi.

Psalmu 67.

KI Ọlọrun ki o ṣãnu fu wa, ki o sì busi i fu wa; ki o sì ṣe oju rẹ̀ ki o mọlẹ si wa lara.
2 Ki ọ̀na rẹ̀ ki o le di mimọ̀ li aiye, ati igbala ilera rẹ̀ ni gbogbo orilẹ ède.
3 Jẹ ki awọn enia ki o yìn ọ, Ọlọrun; jẹ ki gbogbo awọn enia ki o yìn ọ.
4 Jẹ ki inù awọn orilẹ ède ki o dùn, ki nwọn ki o sì ma kọnrin fu ayọ̀ : nitori ti iwọ o fi ododo ṣe idajọ́ awọn enia, iwọ o sì jọba awọn orilẹ ède li aiye.
5 Jẹ ki awọn enia ki o yìn ọ, Ọlọrun; jẹ ki gbogbo awọn enia ki o yìn ọ.
6 Nigbana ni ilẹ yio to ma mu asọnkún rẹ̀ wá; Ọlọrun, Ọlọrun wa tikara rẹ̀ yio busi i fu wa.
7 Ọlọrun yio busi i fu wa; ati gbogbo opin ilẹ aiye yio sì ma bẹ̀ru rẹ̀.

OWURỌ IJỌ. 13.

Psalmu 68.

KI Ọlọrun ki o didè, ki a sì tú awọn ọtá rẹ̀ ká : ki awọn ti o korïra rẹ̀ pẹlu, ki nwọn ki o sálọ kuro niwaju rẹ̀.
2 Bi ẽfin ti ifẹ lọ, bẽni ki o fẹ wọn lọ : bi ida ti iyọ́ niwaju iná, bẽni ki enia buburu ki o ṣegbé niwaju Ọlọrun.
3 Ṣugbọn jẹ ki inu awọn olododo ki o dùn;

Digitized by Google

ki nwọn ki o yọ̀ niwaju Ọlọrun : nitõtọ, ki nwọn ki o yọ̀ gidigidi.

4 Ẹ kọnrin si Ọlọrun, ẹ kọnrin iyìn si orukọ rẹ̀ : ẹ yìn ẹniti ngùn ọrun li ẹṣin nipa JA orukọ rẹ̀, ki ẹ sì ma yọ̀ niwaju rẹ̀.

5 Babba ti awọn alaìni-babba, ati onidajọ́ ti awọn opó, li Ọlọrun ni ibujoko rẹ̀ mimọ́.

6 Ọlọrun gbé ẹni ofo kalẹ ni idile : o mu awọn ti a dè li ẹ̀wọn jade : ṣugbọn awọn ọlọ̀tẹ ni ngbé inu ilẹ gbigbẹ.

7 Ọlọrun, nigbati iwọ jade lọ niwaju awọn enia rẹ, nigbati iwọ nrìn ìrin ogun lọ larin aginjù.

8 Ilẹ mì, awọn ọrun bọ́ silẹ niwaju Ọlọrun : ani Sinai tikara rẹ̀ mì niwaju Ọlọrun, Ọlọrun Israeli.

9 Ọlọrun, iwọ li o rán ọ̀pọlọpọ ọ̀jo, nipa eyi ti iwọ fi fi ẹṣẹ ilẹ-ini rẹ mulẹ, nigbati o rẹ̀ ẹ tan.

10 Ijọ awọn enia rẹ li o tẹdo sinu rẹ̀ : iwọ, Ọlọrun, ninu ore rẹ li o ti pèse fu awọn talakà.

11 OLUWA ti fọhùn ọ̀rọ rẹ̀ : ọ̀pọlọpọ sì li ẹgbẹ awọn ẹniti o wasu rẹ̀ :

12 Awọn ọba ti awọn ẹgbẹ ogun sá, nwọn sá lọ : obiri ti o sì joko ni ile ni npín ikogun na.

13 Bi ẹnyin tilẹ ti dubulẹ larin ìkoko, ṣugbọn ẹnyin o dabi iyẹ́ apa àdaba ti a bò ni fadaka, ati ìhuhu rẹ̀ pẹlu wura pupa.

14 Nigbati Olodumare tú awọn ọba ká ninu rẹ̀, o funfun bi omi didì li òke Salmon.

15 Òke Ọlọrun dabi òke Baṣan; òke giga kan bi òke Baṣan.

16 Ẽṣe ti ẹnyin fi nfò, ẹnyin òke giga? eyi li òke ninu eyi ti Ọlọrun fẹ lati ma gbé; nitõtọ, JEHOFA yio ma gbé ibẹ̀ lailai.

Digitized by Google

17 Ẹgbawa ni kẹkẹ ogun Ọlọrun, ani ẹgbẹgbẹrun awọn angeli : Oluwa mbẹ ninu wọn, bi ti Sinai nibi ọke mimọ́ ni.
18 Iwọ ti gòke si ibi giga, iwọ ti di igbekun ni igbekun lọ : iwọ ti gbà ẹbun fu awọn enia ; nitõtọ, fu awọn ọlọ̀tẹ pẹlu, ki Jehofa Ọlọrun ki o le ma ba wọn gbé.
19 Olubukún li Oluwa, ẹniti ndi ore rù wa lojojumọ, Ọlọrun na ti igbala wa.
20 Ẹniti ṣe Ọlọrun wa li Ọlọrun igbala; ati lọwọ́ Jehofa Oluwa li amuwa lọwọ́ ikú wà.
21 Ṣugbọn Ọlọrun yio fọ́ ori awọn ọtá rẹ̀, ati agbari onirun ti irú ẹniti nrìn sibẹ̀ ninu ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀.
22 Oluwa wipe, emi o tún mu pada lati Baṣan wá, emi o tún mu awọn enia mi pada lati ibú okun na wá :
23 Ki ẹsẹ rẹ ki o le pón ninu ẹ̀jẹ awọn ọtá rẹ, ati ahọn ajá rẹ ninu rẹ̀ na.
24 Nwọn ti ri ìrin rẹ, Ọlọrun; ani ìrin Ọlọrun mi, Ọba mi, ninu ibi mimọ́ ni.
25 Awọn akọnrin lọ niwaju, awọn olohun ọnà orin kẹhin; ninu wọn li awọn ọmmọbiri ti nwọn lù ìlu.
26 Ẹ fi ibukún fu Ọlọrun ninu gbogbo ijọ, ani fu Oluwa, ẹnyin ti o ti orisun Israeli wá.
27 Nibẹ̀ ni Benjamin kekere wà pẹlu olori wọn, awọn ọmmọ alade Juda pẹlu ìgbimọ wọn, awọn ọmmọ alade Sebulon, ati awọn ọmmọ alade Naftali.
28 Ọlọrun rẹ ti paṣẹ agbara rẹ : Ọlọrun, fi agbara fu eyi ti o ti ṣẹ fu wa,
29 Nitori tempeli rẹ ni Jerusalemu li awọn ọba o ma mu ọrẹ fu ọ wá.
30 Ba ẹgbẹ awọn ọlọ̀kọ wi, ọ̀pọlọpọ ti awọn

Digitized by Google

akọ malu, pẹlu awọn ọmmọ malu ti awọn enia, titi olukuluku yio fi foribalẹ pẹlu ìwọn fadaka : o tú awọn enia ti nṣe inu didùn si ogun ká.

31 Awọn ọmmọ alade yio ti Egipti jade wá; nisisiyi ni Etiopia yio nawọ́ rẹ̀ si Ọlọrun.

32 Ẹ kọnrin si Ọlọrun, ẹnyin ilẹ ọbba aiye ; ẹ kọnrin ìyin si OLUWA :

33 Si ẹniti ngùn ati ọrun de ọrun li ẹṣin, nigba atijọ; wò o, o fọhùn rẹ̀ jade, eyi na li ohùn nla.

34 Ẹ fi agbara fu Ọlọrun : ọllá-nla rẹ̀ wà lori Israeli, ati agbara rẹ̀ mbẹ li awọ-sanma.

35 Ọlọrun, iwọ li ẹ̀ru lati inu ibi mimọ́ rẹ wá : Ọlọrun Israeli li on ti o nfi ilera ati agbara fu awọn enia rẹ̀. Olubukún li Ọlọrun.

ALẸ IJỌ. 13.

PSALMU 69.

OLỌRUN, gbà mi là; nitori ti awọn omi wọ̀ inu lọ si ọkkàn mi.

2 Emi rì ninu irà jijin, nibiti ibuduro kò si : emi de inu awọn omi jijìn, nibiti ìṣan-omi ṣàn bò mi lori.

3 Agara ẹkún mi dá mi : ọfọn mi gbẹ : oju kọn mi nigbati emi duro dè Ọlọrun mi.

4 Awọn ti o korira mi lainidi jù irun ori mi lọ : awọn ti nṣe ọtá mi laìṣẹ, ti iba pa mi run, nwọn lagbara : nigbana ni mo san ohun ti emi kò mu.

5 Ọlọrun, iwọ mọ̀ iwère mi, ẹ̀ṣẹ mi kò sì lumọ́ kuro loju rẹ.

6 OLUWA JEHOFA awọn ọmmọ ogun, má ṣe jẹ ki oju ki o tì awọn ti o duro tì ọ nitori

Digitized by Google

mi : má ṣe jẹ ki awọn ti nwá ọ ki o damu nitori mi, Ọlọrun Israeli.

7 Nitori pe nitori ti rẹ li emi ṣe nrù ẹgan; ìtiju ti bò mi loju.

8 Emi di àjeji si awọn arakọnri mi, ati alejò si awọn ọmmọ iya mi.

9 Nitori ti itara ile rẹ ti jẹ mi tan; ati ẹgan awọn ti o gàn ọ ṣubu lù mi.

10 Nigbati mo sọkun, ti mo sì nfi àwẹ jẹ ara mi ni ìya, eyi na sì di ẹgan mi.

11 Emi fi aṣọ ọfọ ṣe aṣọ mi pẹlu; mo sì di ẹni owe fu wọn.

12 Awọn ti o joko li ẹnu ọna nsọ̀rọ si mi; emi sì di orin awọn ọmọti.

13 Ṣugbọn bi o ṣe ti emi ni, adura mi wà sipa rẹ, JEHOFA, ni igba itẹwọgba : Ọlọrun, ninu ọpọlọpọ ãnu rẹ gbohùn mi, ninu otitọ igbala rẹ.

14 Yọ mi kuro ninu ẹrè, má sì ṣe jẹ ki emi rì : gbigbà ni ki a gbà mi lọwọ́ awọn ti o korira mi, ati ninu awọn omi jijìn.

15 Má ṣe jẹ ki ìṣan-omi ki o bò mi mọlẹ, bẽni ki o má ṣe jẹ ki ọgbọn ki o gbé mi mì, ki o má sì ṣe jẹ ki ihò ki o pa ẹnu rẹ̀ de mọ́ mi.

16 JEHOFA, gbohùn mi; nitori ti iṣeun-ifẹ rẹ dara : yipada si mi gẹgẹ bi ọpọlọpọ irọnu ãnu rẹ.

17 Ki o má sì ṣe pa oju rẹ mọ́ kuro lara iranṣẹ rẹ; emi sá wà ninu ipọnju : yara gbohùn mi.

18 Sumọ́ ọkkàn mi, sì rà a pada : gbà mi nitori awọn ọtá mi.

19 Iwọ ti mọ̀ ẹgan mi, ìtiju mi, ati alaìlọlá mi, gbogbo awọn ọtá mi li o wà niwaju rẹ.

20 Ẹgan ti bà mi ninu jẹ; emi sì kún fu ikãnu : emi sì woye fu ẹniti yio ṣãnu fu mi,

Digitized by Google

ṣugbọn kò si; ati fu awọn olutunu, bẹ̃li emi kò sì ri ẹnikan.

21 Nwọn fi orõro fu mi pẹlu li ohun jijẹ mi; ati li ongbẹ mi nwọn fu mi li ọti kikan ni mimu.

22 Jẹ ki aga tabeli wọn ki o di ikẹkun niwaju wọn: ati ohun ti iba ṣe alafia wọn, ki o di okùn didẹ.

23 Jẹ ki oju wọn ki o ṣú, ki nwọn ki o má ṣe riran; ki o sì ma mu ìha wọn gbọ̀n nigbagbogbo.

24 Dà ibinu rẹ si wọn lori, ki ikan-nu ibinu ki o le wọn bà.

25 Ṣe ki ibujoko wọn ki o di ahoro; ki ẹnikẹni ki o má ṣe gbé inu agọ́ wọn.

26 Nitori ti nwọn nṣe inunibini si ẹniti iwọ ti lù; nwọn sì nsọ̀rọ̀ si ibinujẹ ti awọn ti iwọ sì ṣá li ọgbẹ.

27 Fi ẹ̀ṣẹ̀ kún ẹ̀ṣẹ̀ wọn: ki o má sì ṣe jẹ ki nwọn ki o wá sinu ododo rẹ.

28 Nù wọn kuro ninu iwe awọn alãye, ki a má sì kọwe wọn pẹlu awọn olododo.

29 Ṣugbọn talakà ati ẹni ikãnu li emi: jẹ ki igbala rẹ, Ọlọrun, ki o gbé mi leke giga.

30 Emi o fi orin yìn orukọ Ọlọrun, emi o fi ọpẹ́ gbé orukọ rẹ̀ ga.

31 Eyi pẹlu ni yio wù JEHOFA jù ọdá malu tabi akọ malu lọ ti o ni iwo ati bàta ẹṣẹ.

32 Awọn onirẹlẹ yio ri eyi, inu wọn yio sì dùn: ọkkàn ẹnyin ti nwá Ọlọrun yio sì wà lãye.

33 Nitori ti JEHOFA gbohùn awọn talakà, kò sì fi oju pa awọn ara-tubu rẹ̀ rẹ́.

34 Jẹ ki awọn ọrun on aiye ki o yìn i, awọn okun, ati ohun gbogbo ti nrakò ninu wọn.

35 Nitori ti Ọlọrun yio gbà Sion là, yio sì

Digitized by Google

kọ́le awọn ilu-nla Juda: ki nwọn ki o le ma gbé ibè, ki nwọn ki o le ma ni i ni ilẹ-ini.

36 Irú-ọmmọ awọn iranṣẹ rẹ̀ pẹlu ni yio ma jogún rẹ̀: awọn ti o sì fẹ orukọ rẹ̀ ni yio ma gbé inu rẹ̀.

PSALMU 70.

OLỌRUN, yara gbà mi; JEHOFA, yara lati ràn mi lọwọ́.

2 Ki oju ki o tì awọn ti nwá ọkàn mi, ki nwọn ki o sì damu: ki nwọn ki o sì pada sẹhin, ki a sì damu awọn ti nwá ifarapa mi.

3 Ki a pa wọn li ẹhin dà li ère ìtiju awọn ti nwi pe, Ã, ã.

4 Ki gbogbo awọn ti nwá ọ ki o ma yọ̀, ki inu wọn ki o sì ma dùn nipa ti rẹ: ki irú awọn ti o sì fẹ igbala rẹ ki o ma wi nigbagbogbo pe, Ki a gbé Ọlọrun ga.

5 Ṣugbọn talakà ati alaini li emi: Ọlọrun, yara si mi: iwọ ni iranlọwọ ati olugbala mi; JEHOFA, má ṣe pẹ titi.

OWURỌ IJỌ. 14.

PSALMU 71.

JEHOFA, iwọ ni mo gbẹkẹ mi le: lai má ṣe jẹ ki a damu mi.

2 Gbà mi nipa ododo rẹ, ki o sì mu mi yọ: dẹ etí rẹ silẹ si mi, ki o sì gbà mi là.

3 Iwọ ni ki o ṣe ibujoko apatta mi, nibiti emi o gbé ma rè nigba-gbogbo: iwọ ti paṣẹ lati gbà mi là; nitori iwọ li apatta ati odi lagbara mi.

4 Gbà mi, Ọlọrun mi, li ọwọ́ awọn enia buburu, li ọwọ́ alaìṣododo ati ìka ọkọnri.

Digitized by Google

5 Nitori iwọ ni ireti mi, OLUWA JEHOFA; iwọ ni igbẹkẹle mi lati igba ewe mi.

6 Nipa ọwọ́ rẹ li a ti gbé mi duro lati inu wá: iwọ li ẹniti o mu mi jade lati inu iya mi wá: nipasẹ rẹ ni iyìn mi wà nigba-gbogbo.

7 Emi dabi ẹni iyanu fu ọpọlọpọ enia, ṣugbọn iwọ li abò mi ti o lagbara.

8 Jẹ ki ẹnu mi ki o kún fu iyìn ati fu ọllá rẹ li ojọ gbogbo.

9 Má ṣe ṣa mi tì ni igba ogbó; má ṣe kọ̀ mi silẹ nigbati agbara mi ba yẹ̀.

10 Nitori ti awọn ọtá mi nsọ̀rọ si mi; awọn ti nwọn sì nṣọ́ ọkkàn mi gbìmọ pọ̀,

11 Nwọn wipe, Ọlọrun ti kọ̀ ọ silẹ: ṣe inunibini ki ẹ sì mu u; nitori ti kò si ẹniti yio gbà a.

12 Ọlọrun, má ṣe jina si mi: Ọlọrun mi, yara niti iranlọwọ mi.

13 Jẹ ki nwọn ki o damu, ki a sì run awọn ti nṣe ọtá ọkkàn mi; ki a sì fi ẹgan ati àbukun bò awọn ti nwá ifarapa mi.

14 Ṣugbọn emi o ma reti nigba-gbogbo, emi o sì ma yìn ọ sibẹ̀-sibẹ.

15 Ẹnu mi yio ma fi ododo rẹ ati igbala rẹ hàn li ojọ gbogbo; emi kò sá mọ̀ iye rẹ̀.

16 Emi o ma rìn lọ li agbara OLUWA JEHOFA: emi o ma da ọ̀rọ ododo rẹ ṣọ, ani ti rẹ na.

17 Ọlọrun, iwọ ti kọ́ mi lati igba ewe mi wá: ati di isisiyi li emi ti nsọ̀rọ awọn iṣẹ́ iyanu rẹ.

18 Nisisiyi pẹlu, nigbati emi di arugbo tan ti mo hewú, Ọlọrun, má ṣe kọ̀ mi; titi emi o fi fi ipá rẹ hàn fu iran yi, ati agbara rẹ hàn fu gbogbo awọn ara ẹhin.

19 Ọlọrun, ododo rẹ ga jọjọ pẹlu, ẹniti o ti nṣe nkan nla: Ọlọrun, tali o dabi iwọ!

Digitized by Google

20 Iwọ, ti o fi iṣẹ́ nla ati kikan hàn mi, ni yio sì tún mi jí, yio sì tún mu mi sọ si oke lati ọgbọn ilẹ wá.
21 Iwọ o sọ ọllá mi di pupọ̀, iwọ o sì tù mi ni inu niha gbogbo.
22 Emi o sì fi èlo orin mimọ́ yìn ọ pẹlu, ani otitọ rẹ, Ọlọrun mi : iwọ li emi o ma fi dùru kọnrin si, iwọ Ẹni Mimọ́ Israeli.
23 Ète mi yio yọ̀ gidigidi nigbati mo ba nkọnrin si ọ ; ati ọkàn mi, ti iwọ ti rà pada.
24 Ahọn mi pẹlu yio sì ma sọ̀rọ̀ ododo rẹ titi li ọjọ gbogbo : nitori ti nwọn damu, a sì dojutì awọn ti nwá ifarapa mi.

Psalmu 72.

OLỌRUN, fi idajọ́ rẹ fu ọbba, ati ododo rẹ fu ọmmọ ọbba.
2 On yio ma fi ododo ṣe idajọ́ awọn enia rẹ, ati idajọ́ ṣe fu awọn talakà rẹ.
3 Awọn òke nla yio ma mu alafia fu awọn enia wá, ati awọn òke kekere nipa ododo.
4 On yio ma ṣe idajọ́ awọn talakà ninu awọn enia, yio ma gbà awọn ọmmọ ti awọn alalni là, yio sì fà aninilara ya pẹrẹ-pẹrẹ.
5 Nwọn o sì ma bẹ̀ru rẹ niwọn bi õrùn ati oṣupa yio ti pẹ to, lati gbogbo iran-diran.
6 Yio rọ̀ si ilẹ bi òjo si ori koriko irẹ́-mọlẹ : bi ọwọ́ òjo ti o rin ilẹ.
7 Li ọjọ rẹ̀ li awọn olododo yio gbilẹ ; ati ọ̀pọlọpọ alafia niwọn bi oṣupa yio ti pẹ to.
8 On yio sì ni ijọbba lati okun de okun, ati lati odò nla ni de opin ilẹ aiye.
9 Awọn ti o joko li aginjù yio tẹriba fu u ; awọn ọtá rẹ yio sì lá erupẹ̀ ilẹ.
10 Awọn ọbba Tarṣiṣi, ati ti awọn erekuṣu yio mu ọrẹ wá : awọn ọbba Ṣeba ati ti Seba yio mu ẹ̀bun wá.

Digitized by Google

11 Nitõtọ, gbogbo awọn ọbba ni yio wólẹ niwaju rẹ : gbogbo awọn orilẹ èdè ni yio ma sìn i.

12 Nitori ti yio gbà awọn alaìni nigbati nwọn ba nke; talakà pẹlu, ati ẹniti kò li oluranlọwọ.

13 On yio da talakà ati alaìni si, yio sì gbà ọkkàn alaìni là.

14 On yio rà ọkkàn wọn lọwọ ẹ̀tan ati ìwa agbara : iyebiye li ẹ̀jẹ wọn yio sì jẹ li oju rẹ.

15 On yio sì yè, on li a o sì fi wura Ṣeba fu : a o sì ma gbadura fu u nigba-gbogbo; lojojumọ li a o sì ma yìn i.

16 Ikúnwọ ọkà ni yio ma wà lori ilẹ lori awọn òke nla; eso rẹ yio ma mì bi Lebanon : ati awọn ti inu ilu-nla yio sì ma gbà bi koriko ilẹ.

17 Orukọ rẹ yio wà titi lai : orukọ rẹ yio duro pẹ titi to bi ti õrùn : a o sì ma bukún u fu enia nipasẹ rẹ : gbogbo awọn orilẹ èdè ni yio ma pè e li alabukún-fu.

18 Olubukún li Ọlọrun, JEHOFA, Ọlọrun Israeli, ẹnikan ṣoṣo ti nṣe ohun iyanu.

19 Olubukún li orukọ rẹ ti o li ogo titi lai : ki gbogbo aiye ki o sì kún fu ogo rẹ; Amin ati Amin.

20 Adura Dafidi ọmmọkọnri Jese pari.

ALẸ IJỌ. 14.

PSALMU 73.

NITÕTỌ Ọlọrun ṣeun fu Israeli, fu irú awọn ti o ṣe alaiya mimọ.

2 Ṣugbọn bi o ṣe ti emi ni, ẹsẹ mi fẹrẹ yẹ tan; ìrin mi fẹrẹ yọ tan.

Digitized by Google

3 Nitori ti emi ṣe ilara si awọn aṣiwere,
nigbati mo ri alafia ti awọn enia buburu.
4 Nitori ti kò si ọjá ni ikú wọn : ṣugbọn ipá
wọn fi ẹsẹ mulẹ.
5 Nwọn kò wà ninu iyọnu bi awọn ẹlomiran;
bẹ̃ni a kò sì wahalà wọn bi ẹlomiran.
6 Nitorina ni igberaga ṣe fà yi wọn ká bi
ẹ̀wọn ; ìwa-ipa bò wọn mọlẹ bi aṣọ.
7 Oju wọn yọ jade fu isanra : nwọn ni jù bi
ọkkàn wọn ti nfẹ lọ.
8 Nwọn baję, nwọn sì nsọ̀rọ buburu nipa
ininilara : nwọn nsọ̀rọ giga-giga.
9 Nwọn gbé ẹnu wọn le si ọrun, ahọn wọn,
sì nrìn ilẹ aiye já.
10 Nitorina li awọn enia rẹ̀ ṣe yipada si
ihin : omi ago kikún li a sì nfun jade fu wọn.
11 Nwọn sì nwipe, Ọlọrun ti ṣe mọ̀? ìmọ
wà ninu ọgá-ogo?
12 Kiye si i, awọn nwọnyi li alaìwa-bi-
ọlọrun, ẹniti aiye nsan; nwọn npọ̀ li ọrọ̀.
13 Nitõtọ li asan ni mo wẹ̀ àiya mi mọ́, ti
mo sì wẹ̀ ọwọ́ mi li aìlẹṣẹ.
14 Nitori pe li ọjọ gbogbo li a nyọ mi lẹnu,
a sì n-nà mi li orowurọ̀.
15 Bi emi ba pe, emi o fọ̀ bayi; kiye si i,
emi o ṣẹ̀ si iran awọn ọmmọ rẹ.
16 Nigbati mo rò lati mọ̀ eyi, o ṣoro li oju
mi.
17 Titi mo fi lọ sinu ibi mimọ́ Ọlọrun; ni-
gbana ni mo mọ̀ idi wọn.
18 Nitõtọ iwọ gbé wọn kà ibi yiyọ̀ : iwọ sọ
wọn kalẹ lọ sinu iparun.
19 A ti mu wọn lọ sinu idahoro yi, bi ẹnipe
ni iṣẹju kan! ìbẹru li a fi nrun wọn.
20 Bi ẹnipe nigbati ẹnikan ba jí li oju alá;
bẹ̃ni, Oluwa, nigbati iwọ ba jí, iwọ o ṣe àbu-
kun aworan wọn.

Digitized by Google

21 Bayi ni inu mi baję, ęgun sì gún mi li ọkkàn mi.
22 Bẹ̃ni mo ṣiwere, ti mo sì ṣe òpe enia; mo dabi ęranko niwaju rẹ.
23 Ṣugbọn emi wà pẹlu rẹ nigba-gbogbo: iwọ li o ti di ọwọ́ ọtún mi mu.
24 Iwọ o fi ìmọ rẹ tọ́ mi li ọ̀na, ati nigbẹhin iwọ o gbà mi sinu ogo.
25 Tani mo ni li ọrun bikoṣe iwọ? kò sì si ęniti mo fẹ li aiye pẹlu rẹ.
26 Ẹran ara mi ati àiya mi di ãrẹ tan: ṣugbọn Olọrun ni apatta àiya mi, ati ipín mi lailai.
27 Sá kiye si i, awọn ti o jina si ọ yio ṣegbé: iwọ ti pa gbogbo wọn run ti nṣe àgbere kiri-kiri kuro lọdọ rẹ.
28 Ṣugbọn o dara fu mi lati sumọ́ Olọrun: emi ti gbẹkẹ mi le OLUWA JEHOFA, ki emi ki o le ma sọ̀rọ iṣẹ́ rẹ gbogbo.

PSALMU 74.

OLỌRUN, ẽṣe ti iwọ fi ta wa nu titi lai? ẽṣe ti ibinu rẹ fi nru si agutan papa rẹ?
2 Ranti ijọ awọn enia rẹ, ti iwọ ti rà nigba atijọ; ẹ̀ya ilẹ-ini rẹ, ti iwọ ti rà pada; òke Sion yi, ninu eyi ti iwọ ngbé.
3 Gbé ęsẹ rẹ soke si ahoro lailai ni; ani si gbogbo eyi ti ọtá ti fi buburu ṣe ni ibi mimọ́.
4 Awọn ọtá rẹ nke ramu-ramu li arin ijọ awọn enia; nwọn gbé asia wọn soke fu àmi.
5 Bi ọkọnri ti gbé akeke rẹ̀ soke ninu igi pupọ̀ bẹ̃li okikí rẹ yio kàn.
6 Ṣugbọn nisisiyi iṣẹ́ ọnà fifin rẹ̀ ni nwọn fi akeke ati òlu wó lulẹ pọ̀ li ęrinkan.

Digitized by Google

7 Nwọn tinabọ̀ ibi mimọ́ rẹ, ni wiwó ibujoko orukọ rẹ̀ lulẹ, nwọn sọ ọ di ẽri.
8 Nwọn wi li ọkkàn wọn pe, Ẹ jẹ ki a run wọn pọ̀ : nwọn ti kun gbogbo sinagogu Ọlọrun ni ilẹ na.
9 Awa kò ri àmi wa : kò si woli kan mọ́ : bẹ̃ni kò si ẹnikan ninu wa ti o mọ̀ bi yio ti pẹ to.
10 Ọlọrun, ọtá ni yio ti kẹgàn pẹ to? ki ọtá ni ki o ha ma sọ buburu si orukọ rẹ lailai?
11 Ẽṣe ti iwọ fifà ọwọ́ rẹ sẹhin, ani ọwọ́ ọtún rẹ? fà a yọ jade kuro li owokan àiya rẹ.
12 Nitori Ọlọrun li Ọbba mi li atijọ wá, ti nṣiṣe igbala larin ilẹ aiye.
13 Iwọ li o ti yà okun ni meji nipa agbara rẹ : iwọ ti fọ́ ori awọn erinmi ni ninu omi.
14 Iwọ fọ́ ori erinmi tútu, o sì fi i ṣe onjẹ fu awọn enia ti ngbé inu ijù,
15 Iwọ là orisun ati ìṣan-omi : iwọ gbẹ awọn odò nla alagbara.
16 Ti rẹ li ọsán, ti rẹ li oru pẹlu : iwọ li o ti pèse imọlẹ ati õrùn.
17 Iwọ li o ti pàla etí ilẹ aiye : iwọ li o ṣe igba èrun ati igba otutú.
18 Ranti eyi, JEHOFA, pe ọtá nkẹgàn, ati pe awọn enia buburu nsọ̀rọ̀ buburu si orukọ rẹ.
19 Má ṣe fi ọkkàn àdaba rẹ le awọn ọ̀pọ̀ awọn enia buburu lọwọ́ : má ṣe gbagbé ijọ awọn talakà rẹ lailai.
20 Juba majẹmu ni : nitori ti ibi òkunkun ti ilẹ aiye wọn-ni o kún fu ile ìka.
21 Má ṣe jẹ ki ẹniti anilara ki o pada ni ìtiju : ki talakà ati alaìni ki o yìn orukọ rẹ.
22 Ọlọrun, dide gbà ẹjọ́ ara rẹ rò : ranti bi enia buburu ti ngàn ọ lojojumọ.

Digitized by Google

23 Má ṣe gbagbé ohùn awọn ọtá rẹ : irọkẹ̀kẹ awọn ti o dide si ọ npọ̀ si i nigbagbogbo.

OWURỌ̀ IJỌ. 15.

PSALMU 75.

OLỌRUN, iwọ li awa fi ọpẹ́ fu, iwọ li awa fi ọpẹ́ fu : ni ti orukọ rẹ sumọ́ itosi, iṣẹ́ iyanu rẹ fi hàn.

2 Nigbati emi ba gbà ijọ awọn enia, emi o fi otitọ ṣe idajọ́.

3 Ilẹ aiye ati gbogbo awọn ẹni ti ngbé inu rẹ̀ wa-rìri : emi li o rù ọwọ̀n rẹ̀.

4 Emi wi fu awọn aṣiwere, pe Ẹ má ṣe buburu mọ́ : ati fu awọn enia buburu, Ẹ má ṣe gbé iwo ni soke :

5 Ẹ má ṣe gbé iwo nyin ga soke : ẹ má ṣe fi ọrùn lile sọ̀rọ.

6 Nitori ti igbeleke kò ti ìla õrùn wá, tabi ni ìwọ õrùn, bẹ̃ni kì iṣe ati gusù wá.

7 Ṣugbọn Olọrun li onidajọ : o sọ ọkan kalẹ, o sì gbé ẹlomiran leke.

8 Nitori pe li ọwọ́ JEHOFA li ago kan wà, ọti wain na sì pọ́n ; o kún fu àdalu ; o sì dà jade ninu rẹ̀ : ṣugbọn gẹ̀dẹgẹ̀dẹ rẹ̀, gbogbo awọn enia buburu ti ilẹ aiye ni yio fun u li afun mu.

9 Ṣugbọn emi o ma sọ titi lai ; emi o ma kọrin iyìn si Olọrun Jakobu.

10 Gbogbo iwo ti awọn enia buburu li emi o ke kuro ; ṣugbọn iwo ti awọn olododo li emi o gbé leke.

Digitized by Google

Psalmu 76.

NI Juda li a gbé mọ Ọlọrun : orukọ rẹ̀ sì pọ̀ ni Israeli.

2 Ni Salemu pẹlu li agọ́ rẹ̀ wà, ati ibujoko rẹ̀ ni Sion.

3 Nibẹ̀ li o gbé ṣẹ́ ọfà ọrun, ati apata, ati idà, ati ogun na.

4 Iwọ li ogo ati ọlá jù awọn òke nla ọdẹ lọ.

5 A bà awọn alaiya lile jẹ, nwọn ti sùn orun wọn : kò sì si ọkọnri alagbara ti o sì ri ọwọ́ wọn.

6 Nipa ibawi rẹ, Ọlọrun Jakobu, ati kẹ̀kẹ́ ogun ati ẹṣin sùn orun asunkú.

7 Iwọ, ani iwọ li o ni ìbẹ̀ru : ati tani yio le duro niwaju rẹ nigbati iwọ ba binu lẽkan?

8 Iwọ mu idajọ́ di gbigbọ́ lati ọrun wá ; ilẹ̀ aiye bẹ̀ru, o sì duro jẹ.

9 Nigbati Ọlọrun dide si idajọ́, lati gbà gbogbo awọn ọlọkàn tutù ti ilẹ̀ aiye là.

10 Nitõtọ ibinu enia yio yìn ọ : iyokù ibinu ni iwọ o sì ṣe akoso.

11 Ṣe ileri ifẹ́, ki o sì san a fu Jehofa Ọlọrun nyin : jẹ ki gbogbo awọn ti o yi i ká kiri ki o mu ẹ̀bun fu ẹniti a ba ma bẹ̀ru wá.

12 On yio ke ẹmí ti awọn ọmọ́ alade kuro : o sì di ẹ̀ru si awọn ọba ti ilẹ̀ aiye.

Psalmu 77.

EMI fi ohùn mi kigbe si Ọlọrun, ani si Ọlọrun ni mo fi ohùn mi kepè ; ó sì fi etí si mi.

2 Li ọjọ́ ipọnju mi, emi ṣe afẹri Ọlọrun : ọwọ́ mi n-nà li oru, kò sì da : ọkàn mi kọ̀ atitù ninu.

Digitized by Google

3 Emi ranti Ọlọrun, ara mi kò lelẹ : emi ṣe aroye, ẹmmí mi sì di bibò mọlẹ.
4 Iwọ mu oju mi jí : ẹnu yọ mi tobẽ ti emi kò le sọ̀rọ.
5 Emi ti nrò awọn ọjọ atijọ, awọn ọdún igbani.
6 Mo ranti orin mi li oru : emi mba àiya mi sọ̀rọ : ọkkàn mi sì nṣe awari jọjọ.
7 Ọlọrun yio ha ṣa ni tì lailai? kì yio sì ṣe oju rere mọ́?
8 Ãnu rẹ lọ lailai? ileri rẹ yẹ titi lai?
9 Ọlọrun ha gbagbé lati ṣe oju rere? ninu ibinu rẹ o ha sé irọnu ãnu rẹ mọ́?
10 Emi sì wipe, Eyi li allera mi : ṣugbọn emi o ranti ọdún ti ọwọ́ ọtún ọgá-ogo.
11 Emi o ranti iṣẹ́ JEHOFA : nitõtọ emi o ranti iṣẹ́ iyanu rẹ atijọ.
12 Emi o ma ṣe aṣaro gbogbo iṣẹ́ rẹ pẹlu, emi o sì ma sọ̀rọ iṣẹ́ rẹ.
13 Ọlọrun ọna rẹ mbẹ ninu ibi mimọ́ : tali Ọlọrun ti o tobi to bi Ọlọrun wa?
14 Iwọ li Ọlọrun ti nṣe iṣẹ́ iyanu : iwọ li o ti fi ipá rẹ hán ninu awọn enia.
15 Iwọ li o ti fi apa rẹ rà awọn enia rẹ pada, awọn ọmmọkọnri Jakobu ati Josefu.
16 Awọn omi ri ọ, Ọlọrun, awọn omi ri ọ; ẹ̀ru bà wọn : ara ibú kò balẹ.
17 Awọ-sanma dà omi silẹ : oju awọ-sanma rán iró jade : ọfà rẹ jade lọ pẹlu.
18 Ohùn ãrá rẹ mbẹ li ọrun : manamana nkọ si aiye, ilẹ wa-rìri, o sì mì.
19 Ọna rẹ mbẹ li okun, ati ipa rẹ ninu awọn omi nla, ipasẹ rẹ li a kò sì mọ̀.
20 Iwọ dà awọn enia rẹ bi ọwọ́ ẹran nipa ọwọ́ Mose ati Aaron.

Digitized by Google

ALẸ IJỌ. 15.

PSALMU 78.

FI etí silẹ, ẹnyin enia mi, si ofin mi : dẹ etí nyin silẹ si ọ̀rọ ẹnu mi.

2 Emi o ya ẹnu mi li owe : emi o sọ ọ̀rọ atijọ jade.

3 Ti awa ti gbọ́, ti a sì ti mọ̀ ti awọn babba wa sì ti sọ fu wa.

4 Awa kì yio pa wọn mọ́ kuro lọdọ awọn ọmmọ wọn, ni fifi iyìn JEHOFA, ati ipá rẹ̀, ati iṣẹ́ iyanu ti o ti ṣe hàn.

5 Nitori ti o gbé ẹrí kalẹ ni Jakobu, o sì sọ ofin kan ni Israeli, ti o ti pa li aṣẹ fu awọn babba wa pe, ki nwọn ki o le sọ wọn di mimọ̀ fu awọn ọmmọ wọn :

6 Ki awọn iran ti mbọ̀ ki o le mọ̀ wọn, ani awọn ọmmọ ti a o bí ; ti yio sì dide, ti yio sì sọ wọn fu awọn ọmmọ wọn :

7 Ki nwọn ki o le ma gbé ireti wọn le Ọlọrun, ki nwọn ki o má sì ṣe gbagbé iṣẹ́ Ọlọrun, bikoṣepe ki nwọn ki o pa ofin rẹ̀ mọ́.

8 Ki nwọn ki o má ṣe dabi awọn babba wọn, iran agídi ati ọlọ̀tẹ ; iran ti kò fi ọkàn wọn le títọ, ati ọkàn ẹniti kò ba Ọlọrun duro ṣinṣin.

9 Awọn ọmmọ Efraimu ti o hamọra ogun, ti nwọn mu ẹrun, nwọn yipada li ọjọ ogun.

10 Nwọn kò pa majẹmu Ọlọrun mọ́, nwọn sì kọ̀ lati ma rìn ninu ofin rẹ̀ ;

11 Nwọn sì gbagbé iṣẹ́ rẹ̀, ati iṣẹ́ iyanu ti o ti fi hàn fu wọn.

12 Ohun iyanu ti o ṣe li oju awọn babba wọn, ni ilẹ Egipti, ati ni igbẹ́ Soan.

13 O pín okun ni lya, o sì mu wọn là a já ; o sì mu omi duro ni bèbe.

Digitized by Google

14 Li ọsán pẹlu o fi awọ-sanma ṣe amọ̀na wọn, ati li oru gbogbo pẹlu imọlẹ iná.
15 O sán apatta li aginjù, o sì fu wọn li omi mimu bi ẹnipe lati inu ibú wá.
16 O mu ìṣan-omi jade wá pẹlu ninu apatta, o sì mu omi ṣàn silẹ bi odò nla.
17 Nwọn sì tún ṣẹ̀ si i nipa imu ọgá-ogo binu li aganjù.
18 Nwọn sì dan Ọlọrun wò li ọkàn wọn ni bibère ẹran fu ifẹkufẹ wọn.
19 Nitõtọ, nwọn sọ̀rọ si Ọlọrun; nwọn wipe, Ọlọrun le tẹ́ onjẹ silẹ li aginjù?
20 Kiye si i, o lù apatta ti omi sì tú jade, ti ìṣan-omi sì ru jade; o le fu-ni li akara pẹlu? o le pèse ẹran fu awọn enia rẹ̀?
21 Nitorina JEHOFA gbọ́ eyi, o binu : bẽni iná ràn si Jakobu, ibinu pẹlu sì wá si Israeli;
22 Nitori ti nwọn kò gbà Ọlọrun gbọ́, nwọn kò sì gbẹkẹle igbala rẹ̀.
23 Bi o ti paṣẹ fu awọ-sanma lati oke wá ni, ti o sì ṣí ilẹkun ọrun silẹ.
24 Ti o sì rọ̀jo Mana silẹ fu wọn ni jijẹ, ti o sì fu wọn li ọ̀ka ọrun.
25 Enia jẹ onjẹ awọn angeli : o rán onjẹ si wọn li ajẹyo.
26 O mu afẹfẹ ìla-õrùn fẹ li ọrun, ati nipa agbara rẹ̀ o mu afẹfẹ gusù wá.
27 O rọ̀jo ẹran si wọn pẹlu bi erupẹ̀ ilẹ, ati ẹ̃iyẹ abiyẹ bi iyanrin okun.
28 O sì jẹ ki o bọ́ si arin ibudo wọn, yi agọ́ wọn ká.
29 Bẽni nwọn jẹ, ti nwọn sì yó jọ̀jọ : nitori ti o fi ifẹ́ wọn fu wọn.
30 Nwọn kò sì ṣe àjeji si ifẹkufẹ wọn. Ṣugbọn nigbati ẹran wọn sì wà li ẹnu wọn,
31 Ibinu Ọlọrun de si ori wọn, o sì pa awọn

Digitized by Google

ti o sanra julọ ninu wọn, o sì lù awọn ọmmọ-kọnri Israeli bolẹ.

32 Ninu gbogbo nwọnyi nwọn nṣẹ̀ si i, nwọn kò sì gbà iṣẹ́ iyanu rẹ̀ gbọ́.

33 Nitorina li o ṣe run ọjọ wọn li asan, ati ọdún wọn ni ipọnju.

34 Nigbati o pa wọn, nigbana ni nwọn wá a kiri : nwọn sì pada, nwọn bère Ọlọrun ni kutukutu.

35 Nwọn sì ranti pe, Ọlọrun li apatta wọn, ati Ọlọrun ọgá-ogo li oludande wọn.

36 Ṣugbọn ẹnu wọn ni nwọn fi pọ́n ọ, nwọn sì fi ahọn wọn ṣeke si i.

37 Nitori ọkkàn wọn kò ṣe dede pẹlu rẹ̀, bẹ̃ni nwọn kò sì duro ṣinṣin ni majẹmu rẹ̀.

38 Ṣugbọn on, o kún fu iyọnu, o fi ẹ̀ṣẹ̀ wọn jì wọn, kò sì run wọn : nitõtọ, nigba pupọ̀ li o yi ibinu rẹ̀ pada, ti kò sì ru gbogbo ibinu rẹ̀ soke.

39 Nitori ti o ranti pe enia ṣá ni nwọn; afẹfẹ ti nkọja lọ ti kò sì tún pada wá mọ́.

40 Igba melo-melo ni nwọn ṣọ̀tẹ̀ si i li aginjù, ti nwọn sì bà a ninu jẹ ninu aṣálẹ !

41 Nitõtọ, nwọn yipada, nwọn sì dan Ọlọrun wò, nwọn sì ṣe aropin Ẹni Mímọ́ Israeli.

42 Nwọn kò ranti ọwọ́ rẹ̀, tabi ọjọ ni ti o gbà wọn lọwọ́ ọtá wọn ni.

43 Bi o ti ṣiṣẹ̀ àmi rẹ̀ ni Egipti, ati iṣẹ́ iyanu rẹ̀ ni igbẹ́ Soan.

44 Ti o sì sọ awọn odò wọn di ẹ̀jẹ ; ati omi ṣiṣàn wọn, ti nwọn kò fi le mu u.

45 O rán onirũru eṣinṣin sinu wọn, ti o jẹ wọn; ati ọpọlọ́, ti o run wọn.

46 O fi eso ilẹ̀ wọn fu kòkoro pẹlu, ati iṣẹ́ wọn fu eṣú.

47 O fi yinyín pa ajara wọn, o sì fi yinyín nla pa igi sikomore wọn.

Digitized by Google

48 O fi ohun ọ̀sin wọn pẹlu fu yinyín, ati agbo ẹran wọn fu manamana gbigbona.
49 O mu kikorò ibinu rẹ̀ wá si wọn lara, irunu, ati ikan-nu, ati ipọnju, nipa ríran angeli buburu sinu wọn.
50 O ṣina silẹ fu ibinu rẹ̀; kò da ọkkàn wọn si lọwọ́ ikú, ṣugbọn o fi ẹmmí wọn fu ajakalẹ arun;
51 O sì kọlù gbogbo awọn akọbi ni Egipti, olu agbara wọn ninu awọn agọ́ Hamu:
52 Ṣugbọn o mu awọn enia ti rẹ̀ lọ bi agutan, o sì ṣe itọju wọn ni ijù bi agbo ẹran.
53 O sì ṣe amọ̀na wọn li alafia, bẹ̃ni nwọn kò sì bẹ̀ru: ṣugbọn okun bò awọn ọtá wọn mọlẹ.
54 O sì mu wọn wá si etí ibi mimọ́ rẹ̀, si òke yi, ti ọwọ́ ọtún rẹ̀ ti rà.
55 O tì awọn keferi jade pẹlu kuro niwaju wọn, o sì fi tita okùn pinlẹ fu wọn ni ilẹ-ini, o sì mu awọn ẹ̀ya Israeli joko ninu agọ́ wọn.
56 Ṣugbọn nwọn dan a wò, nwọn sì bi Ọlọrun ọgá-ogo ninu, nwọn kò sì pa ẹrí rẹ̀ mọ́.
57 Ṣugbọn nwọn yipada nwọn ṣe alṣotitọ bi babba wọn: nwọn sì pẹhinda si apakan bi ọrun ẹ̀tan.
58 Nitori ti nwọn fi awọn ibi giga wọn bi i ninu, nwọn sì fi ere fifin wọn mu u jowú.
59 Nigbati Ọlọrun gbọ́ eyi, o binu o sì korira Israeli gidigidi.
60 Bẹ̃li o kọ̀ agọ́ Ṣilo silẹ, agọ́ ti o pa ninu awọn enia.
61 O sì fi agbara rẹ̀ fu igbekun, ati ogo rẹ̀ si ọwọ́ ọtá ni.
62 O fi awọn enia rẹ̀ fu idà pẹlu; o sì binu si awọn enia ilẹ rẹ̀.

Digitized by Google

63 Iná run awọn ọmmọkọnri wọn; a kò sì sìn awọn wundia wọn ni iyawo.
64 Awọn alufa wọn ti ipa oju idà ṣubu; awọn opó wọn kò sì pohunrere ẹkún.
65 Nigbana li Oluwa jí bi ẹnipe loju orun, ati bi alagbara ti o nkọ nitori ọti wain.
66 O sì kọlù awọn ọtá rẹ̀ lẹhin: o sọ wọn di ẹgan titi aiye.
67 Pẹlu-pẹlu o kọ̀ agọ́ Josefu, kò sì yàn ẹya Efraimu:
68 Ṣugbọn o yàn ẹya Juda, òke Sion ti o fẹ.
69 O sì kọ́ ibi mimọ́ rẹ̀ bi afin giga, bi ilẹ ti o ti fi idi rẹ̀ mulẹ lailai.
70 O sì yàn Dafidi iranṣẹ rẹ̀, o sì mu u kuro lati inu awọn agbo agutan wá:
71 Lati ma tọ́ awọn abo agutan lẹhin ti o tobi fu oyún, o mu u lati ma bọ́ Jakobu awọn enia rẹ̀, ati Israeli awọn enia ilẹ rẹ̀.
72 Bẽli o bọ́ wọn gẹgẹ bi ìwa títọ inu rẹ̀; o sì ṣe amọ̀na wọn nipa ọgbọ́n ọwọ́ rẹ̀.

OWURỌ IJỌ. 16.

Psalmu 79.

OLỌRUN, awọn keferi wá si ilẹ-ini rẹ; tempeli mimọ́ rẹ ni nwọn sọ di ẽri; nwọn sọ Jerusalemu di òkiti alapa.
2 Okú ti awọn iranṣẹ rẹ ni nwọn fifu ẹ̃iyẹ oju ọrun onjẹ, ẹran ara ti awọn enia mimọ́ rẹ fu ẹranko ti ilẹ aiye.
3 Ẹ̀jẹ wọn ni nwọn ta silẹ bi omi yi Jerusalemu ká; kò sì si ẹnikẹni ti yio gbé wọn sin.
4 Awa di ẹgan si awọn aladugbo wa, ẹlẹya ati iyọsuti si awọn ti o wà yi wa ká.

Digitized by Google

5 Yio ti pẹ to, JEHOFA? iwọ o binu titi lailai? owú rẹ yio ma jó bi iná?
6 Dà ibinu rẹ si ori awọn keferi ti kò mọ ọ, ati si ori awọn ilẹ ọbba ti kò kepè orukọ rẹ.
7 Nitori ti nwọn ti mu Jakobu jẹ, nwọn sì sọ ibujoko rẹ di ahoro.
8 Má ṣe ranti ẹṣẹ wa atijọ si wa : jẹ ki iyọnu rẹ ki o ṣaju wa nisisiyi : nitori ti a rẹ wa silẹ gidigidi.
9 Ràn wa lọwọ, Ọlọrun igbala wa, nitori ogo orukọ rẹ : ki o sì gbà wa, ki o sì wẹ ẹṣẹ wa nù, nitori orukọ rẹ.
10 Nitori kili awọn keferi yio ṣe wipe, Nibo li Ọlọrun wọn wà? jẹ ki a mọ ọ ninu awọn keferi li oju wa nipa igbẹsan ẹjẹ ti awọn iranṣẹ rẹ, ti a ta silẹ.
11 Jẹ ki imí-ẹdọn ti ondè ni ki o wá siwaju rẹ; gẹgẹ bi òpọ agbara rẹ, iwọ da awọn ti a yàn si pipa silẹ;
12 Ki o sì san ẹgan wọn nigba meje fu awọn aladugbo wa li àiya wọn, nipa eyi ti nwọn fi ngàn ọ, OLUWA.
13 Bẹli awa awọn enia rẹ ati agutan papa rẹ, yio ma fi ọpẹ fu ọ lailai : awa o ma fi iyìn rẹ hàn lati iran-diran.

PSALMU 80.

FI etí si ni, Oluṣọ agutan Israeli, iwọ ti o ndà Josefu bi ọwọ́ agutan; iwọ ti o joko larin awọn kerubu, tàn imọlẹ jade.
2 Niwaju Efraimu ati Benjamin ati Manase ru ipá rẹ soke, sì wá fu igbala wa.
3 Tún wa yipada, Ọlọrun, ki o sì mu oju rẹ tàn imọlẹ; a o sì gbà wa là.

Digitized by Google

4 JEHOFA Ọlọrun awọn ọmmọ ogun, iwọ o ti binu pẹ to si adura awọn enia rẹ?
5 Iwọ fi onjẹ omije bọ́ wọn; iwọ sì fu wọn li omije mu li ọpọlọpọ.
6 Iwọ sọ wa di ìja fu awọn aladugbo wa: awọn ọtá wa sì nrẹrin ninu ara wọn.
7 Tún wa yipada, Ọlọrun awọn ọmmọ ogun, ki o sì ṣe oju rẹ ki o mọlẹ; a o sì gbà wa là.
8 Iwọ mu ajara kan jade ti Egipti wá: iwọ ti tì awọn keferi jade, iwọ sì gbìn i.
9 Iwọ ṣe àye silẹ fu u, iwọ sì mu u ta gbongbo jinlẹ, o sì kún ilẹ na.
10 Awọn òke sì bò mọlẹ nipa ojiji rẹ, ati ẹká rẹ dabi igi opepe daradara.
11 O yọ ẹká rẹ sinu okun, ati ọwọ́ rẹ si odò nla ni.
12 Ẽṣe ti iwọ ha fi ya ọgbà rẹ, bẽ ti gbogbo awọn ẹniti nkọja lọ li ọna nká a?
13 Ìmado lati inu igbó wá mbà a jẹ, ati ẹranko igbẹ́ njẹ ẹ.
14 Yipada, awa mbẹ ọ, Ọlọrun awọn ọmmọ ogun: wò ilẹ lati ọrun wá, ki o sì wò o, ki o sì bẹ ajara yi wò;
15 Ati agbala ajara ti ọwọ́ ọtún rẹ ti gbìn, ati ẹká ti iwọ mulẹ fu ara rẹ.
16 O jóna, a ke e lulẹ: nwọn ṣegbé nipa ibawi oju rẹ.
17 Jẹ ki ọwọ́ rẹ ki o wà lara ọkọnri ti ọwọ́ ọtún rẹ ni, lara ọmmọ ọkọnri ti iwọ sọ di agbara fu ara rẹ.
18 Bẽli awa kì yio pada sẹhin kuro lọdọ rẹ: mu wa yè, awa o sì ma pè orukọ rẹ.
19 Tún wa yipada, JEHOFA Ọlọrun awọn ọmmọ ogun, ṣe oju rẹ ki o mọlẹ; a o sì gbà wa là.

Digitized by Google

Psalmu 81.

KỌNRIN soke si Ọlọrun ipá wa : ẹ hó ihó ayọ̀ si Ọlọrun Jakobu.
2 Ẹ mu orin mimọ́, ki ẹ sì mu ìlu wá, dùru didun pẹlu èlo orin mimọ́.
3 Ẹ fun ìpe li oṣù titun, nigba ti a làna silẹ, li ọjọ́ ajọ́ ti o ni ironu.
4 Nitori eyi li aṣẹ fu Israeli, ati ofin ti Ọlọrun Jakobu.
5 Eyi li o làna fu Josefu fu ẹrí, nigbati o kọja ilẹ Egipti jade : nibiti mo gbé gbọ́ ède ti kò yé mi.
6 Mo gbé ejika rẹ̀ kuro ninu ẹrù : a sì gbà ọwọ́ rẹ lọwọ́ awọn ìkoko.
7 Iwọ pè ninu ipọnju, emi sì gbà ọ là ; emi da ọ lohùn nibi ìkọkọ ãrá : emi ri idi rẹ nibi omi Meriba.
8 Ẹ gbọ́, ẹnyin enia mi, emi o sì sọ fu ọ : Israeli, bi iwọ ba fetisi mi ;
9 Kì yio si ọlọrun omiran ninu nyin ; bẽni iwọ kì yio sìn ọlọrun àjeji.
10 Emi ni Jehofa Ọlọrun rẹ, ti o mu ọ lati ilẹ Egipti jade wá : yà ẹnu rẹ gbòro, emi o sì kún u.
11 Ṣugbọn awọn enia mi kò fẹ gbọ́ ohùn mi ; Israeli kò sì fẹ ti emi.
12 Bẽni mo fi wọn silẹ si ifẹkufẹ inu wọn : nwọn sì nrìn ninu ìmọ ara wọn.
13 Iba ṣepe awọn enia mi ti gbọ́ ti emi, ati ki Israeli ki o ma rìn nipa ọna mi !
14 Emi iba ti ṣẹ́ awọn ọtá wọn lógan, emi iba sì ti yi ọwọ́ mi pada si awọn ọtá wọn.
15 Awọn onirera Jehofa iba ti fi ori wọn balẹ fu u : ṣugbọn igba ti wọn iba duro pẹ titi.
16 Alikama daradara ni emi iba ma fi bọ́

Digitized by Google

wọn pẹlu : ati oyin inu apatta ni emi iba sì ma fi tẹ́ wọn lọrùn.

ALẸ IJỌ. 16.

Psalmu 82.

OLỌRUN duro ninu ijọ awọn alagbara ; o nṣe idajọ́ ninu awọn ọlọrun.

2 Ẹnyin o ti ṣe idajọ́ alṣõtọ pẹ to, ti ẹ o sì ma ṣe ojusaju awọn enia buburu ?

3 Ṣe idajọ́ talakà, ati ti alaìni-babba : ṣe otitọ si awọn olupọnju ati alaìni.

4 Gbà talakà ati alaìni : yọ wọn li ọwọ́ awọn enia buburu.

5 Nwọn kò mọ̀, bẽni nwọn kò fẹ ki oyé ki o yé wọn ; nwọn nrìn li òkunkun ; gbogbo ipilẹ ti ilẹ aiye yẹ̀ ni ipò wọn.

6 Emi ti wipe, Awọn ọlọrun li ẹnyin ; awọn ọmmọ ọgá-ogo sì ni gbogbo nyin.

7 Ṣugbọn ẹnyin o kú bi enia, ẹnyin o sì ṣubu bi ọkan ninu awọn ọmmọ-alade.

8 Ọlọrun, dide, ṣe idajọ́ ilẹ aiye : nitori iwọ ni yio ni orilẹ ède gbogbo.

Psalmu 83.

MÁ ṢE dakẹ, Ọlọrun : má ṣe pa ẹnu rẹ mọ́, ki o má sì ṣe duro jẹ, Ọlọrun.

2 Sá wò o, awọn ọtá rẹ nrọkẹ̀kẹ : awọn ti o korira rẹ ti gbé ori wọn soke.

3 Nwọn ti gbìmọ arekereke si awọn enia rẹ, nwọn sì ti gbìro si awọn ẹni ìkọkọ rẹ.

4 Nwọn ti wipe, Ẹ wá, ẹ jẹ ki a ke wọn kuro lati ma wà li orilẹ ède ; ki orukọ Israeli ki o má ṣe sì ni iranti mọ́.

Digitized by Google

5 Nitori ti nwọn ti gbìmọ pọ̀ ṣọkan : nwọn ti dìmọlu si ọ.
6 Awọn agọ́ Edomu, ati ti awọn Iṣmaelite ; ti Moabu, ati awọn Hagarene.
7 Gebali, ati Amon, ati Amaleki ; awọn Filistine pẹlu awọn ara Tire ;
8 Asuru pẹlu dàpọ mọ́ wọn : nwọn ràn awọn ọmmọ Lotu lọwọ́.
9 Ṣe wọn bi o ti ṣe awọn ara Midian ; bi Sisera, bi Jabin, li odò Kison.
10 Ẹniti o ṣegbé ni Endoru : nwọn dabi ilẹdu fu ilẹ.
11 Ṣe awọn ọlọlá wọn bi Orebu ati bi Sẽbu : ani, gbogbo awọn ọmmọ-alade wọn bi Seba, ati Salmuna.
12 Ẹniti o wipẹ, Ẹ jẹ ki a gbà awọn ile Ọlọrun fu ara wa ni ilẹ-ini.
13 Ọlọrun mi, ṣe wọn bi kẹkẹ́ ; bi akeku koriko niwaju afẹfẹ.
14 Bi iná ti jó igi, ati bi ọwọ́ iná ti mu òke nla gbiná ;
15 Bẽni ki o fi ẹfufu rẹ ṣe inunibini si wọn, ki o sì fi ẹfufu rẹ dẹrubà wọn.
16 Fi ìtiju kún wọn li oju ; ki nwọn ki o le ma ṣe afẹri orukọ rẹ, JEHOFA.
17 Ki nwọn ki o damu ki a pọ́n wọn loju lailai ; ani, ki a dojutì wọn, ki nwọn ki o gbé.
18 Ki awọn enia ki o le mọ̀ pe iwọ, orukọ ẹnikan ṣoṣo ti ijẹ JEHOFA, iwọ li ọgá-ogo lori ilẹ aiye gbogbo.

PSALMU 84.

AGỌ́ rẹ wọn-ni ti li ẹwà to, JEHOFA awọn ọmmọ ogun !
2 Ọkkàn mi nfà, nitọ̀tọ, o tilẹ pe o ngbẹ fu

Digitized by Google

ile JEHOFA : àiya mi ati ara mi nkigbe soke fu Ọlọrun alãye.

3 Nitõtọ, ologoṣẹ ri ile kan, ati alapandẹdẹ tẹ itẹ kan fu ara rẹ̀, nibiti yio gbé ma pa awọn ọmmọ rẹ̀ mọ́ si, ani ni awọn pepele rẹ̀, JEHOFA awọn ọmmọ ogun, Ọbba mi, ati Ọlọrun mi.

4 Ibukún ni fu awọn ti ngbé inu ile rẹ̀ : nwọn o ma yìn ọ sibẹ̀.

5 Ibukún ni fu ọkọnri na ipá ẹniti o wà lọwọ́ rẹ̀ : li ọkkàn ẹniti ọ̀na rẹ̀ wà.

6 Ẹniti nlà afonifoji omije lọ, o sọ ọ di kanga; ọjo sì kún ihò wọn-ni.

7 Nwọn nlọ lati ipá de ipá, ni Sion ni nwọn yọ niwaju Ọlọrun.

8 JEHOFA Ọlọrun awọn ọmmọ ogun, gbọ́ adura mi : fi etí si i, Ọlọrun Jakobu.

9 Kiye si i, Ọlọrun asà wa, ki o sì ṣiju wò oju ẹni atorórosi rẹ̀.

10 Nitori pe ọjọ́ kan ninu ile rẹ̀ o sanjù ẹgbẹ̀run ọjọ́ lọ. Mo fẹ̀ ki nkuku ma ṣe ìdena ni ile Ọlọrun mi, jù lati ma gbé agọ́ awọn enia buburu.

11 Nitori JEHOFA Ọlọrun li õrùn ati asà : JEHOFA yio fu-ni li ore-ọfẹ̀ ati ogo : kò si ohun rere ti yio fà sẹ̀hin lọwọ́ awọn ti nrìn dede.

12 JEHOFA awọn ọmmọ ogun, ibukún ni fu oluwarẹ̀ na ti o gbẹ̀kẹ̀le ọ.

PSALMU 85.

JEHOFA, iwọ ti nṣe oju-rere si ilẹ̀ rẹ̀ : iwọ ti mu igbekun Jakobu pada bọ̀.

2 Iwọ ti dari ẹ̀ṣẹ̀ awọn enia rẹ̀ jì, iwọ ti bò ẹ̀ṣẹ̀ wọn mọlẹ̀.

3 Iwọ ti mu gbogbo ibinu rẹ̀ kuro : iwọ

Digitized by Google

ti yi ara rẹ pada kuro ninu pipọn iná oju ti ibinu rẹ.

4 Yi wa pada Ọlọrun igbala wa, ki o sì mu ibinu rẹ si wa ki o dá.

5 Iwọ o binu si wa titi lai? iwọ o fà ibinu rẹ jade lati iran-diran?

6 Iwọ kì yio tun mu wa sọji: ki awọn enia rẹ ki o ma yọ si ọ?

7 JEHOFA fi ãnu rẹ hàn fu wa, ki o sì fu wa ni igbala rẹ.

8 Emi o gbọ́ bi Ọlọrun JEHOFA yio ti wi: nitori ti yio sọ alafia si awọn enia rẹ̀, ati si awọn enia mimọ́ rẹ̀: ṣugbọn ki nwọn ki o má tún pada si wère.

9 Nitõtọ igbala rẹ̀ sumọ́ awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀; ki ogo ki o le ma gbé ilẹ wa.

10 Ãnu ati otitọ pade ara; ododo ati alafia ti fi ẹnu kò ara wọn li ẹnu.

11 Otitọ yio ru jade lati ilẹ wá; ododo yio sì bojuwò ilẹ lati ọrun wá.

12 Nitõtọ, JEHOFA yio fu-ni li eyi ti o dara; ilẹ wa yio sì ma mu asọnkun rẹ̀ wá.

13 Ododo yio ṣaju rẹ̀; yio sì fi wa le ipasẹ rẹ̀.

OWURỌ IJỌ. 17.

PSALMU 86.

JEHOFA, dẹ etí rẹ silẹ, gbohùn mi: nitori ti emi ṣe talakà ati alaìni.

2 Pa ọkàn mi mọ́; nitori emi li ẹniti iwọ ṣe oju-rere fu: iwọ Ọlọrun mi, gbà, ọmmọ ọdọ rẹ ti o gbẹkẹ̀ le ọ.

3 Ṣãnu fu mi, OLUWA: nitori iwọ li emi nkepè lojojumọ.

4 Mu ọkàn iranṣẹ rẹ yọ̀: OLUWA, nitori iwọ ni mo gbé ọkàn mi soke si.

Digitized by Google

5 Nitori iwọ, Oluwa, o ṣeun o sì mura ati darijì; o sì pọ̀ li ãnu fu gbogbo awọn ti nkepè orukọ rẹ.

6 Jehofa, fi etí si adura mi; ki o sì fiye si ohùn ẹ̀bẹ mi.

7 Li ọjọ ipọnju mi, emi o kepè ọ : nitori ti iwọ o gbọ́ ohùn mi.

8 Oluwa, ninu awọn ọlọrun gbogbo kò si eyi ti o dabi rẹ; bẹ̃ni kò si iṣẹ́ kan ti o dabi iṣẹ́ rẹ.

9 Gbogbo awọn orilẹ ède ti iwọ da ni yio wá, nwọn yio sì sìn niwaju rẹ, Oluwa; nwọn o sì ma fi ogo fu orukọ rẹ.

10 Nitori pe iwọ pọ̀, iwọ sì nṣe ohun iyanu : iwọ nikan li Ọlọrun.

11 Jehofa, kọ́ mi li ọ̀na rẹ; emi o ma rìn ninu otitọ rẹ : mu àiya mi ṣọkan lati bẹ̀ru orukọ rẹ.

12 Emi o yìn ọ, Oluwa Ọlọrun mi, tinutinu mi gbogbo : emi o sì ma fi ogo fu orukọ rẹ titi lai.

13 Nitori pe nla li ãnu rẹ si mi : iwọ sì ti gbà ọkàn mi lọwọ́ isà okú jiji.

14 Ọlọrun, awọn agberaga dide si mi, ati awọn ijọ awọn enia alagbara nwá ọkàn mi kiri; nwọn kò sì fi ọ pè li oju wọn.

15 Ṣugbọn iwọ, Oluwa, li Ọlọrun ti o kún fu ãnu, ati olore ọfẹ, olupamọra, o sì pọ̀ li ãnu ati otitọ.

16 Yipada si mi, ki o sì ṣãnu fu mi; fi ipá rẹ fu iranṣẹ rẹ, ki o sì gbà ọmmọkọnri ti iranṣẹ obiri rẹ là.

17 Fi àmi kan hàn mi fu rere; ki awọn ti o korira mi ki o le ri i, ki oju ki o le tì wọn : nitori iwọ, Jehofa, li o ti ràn mi lọwọ́, ti o sì tù mi ninu.

Digitized by Google

Psalmu 87.

IPILẸ rẹ mbẹ lori awọn òke mimọ́.
2 Jehofa fẹ ẹnu ọna Sion jù gbogbo ibujoko Jakobu lọ.
3 Ohun ogo li a nsọ si ọ, Ilu-nla Ọlọrun.
4 Emi o da orukọ Rahabu ati Babilon fu awọn ti o mọ̀ mi : kiye si Filistia, ati Tire, pẹlu Etiopia; a bí ọkọnri yi nibẹ̀.
5 Ati ni Sion li a o wipe, Ọkọnri yi ati ọkọnri ni li a bí ninu rẹ : ati ọgá-ogo tikara rẹ̀ ni yio fi ẹsẹ rẹ mulẹ.
6 Jehofa yio kà, nigbati o ba nkọ orukọ awọn enia, pe a bí ọkọnri yi nibẹ̀.
7 Ati awọn olorin ati awọn ti nlù ohun ọnà orin yio wà nibẹ̀ : gbogbo irú mi mbẹ lara rẹ.

Psalmu 88.

JEHOFA Ọlọrun igbala mi, emi ti nkigbe lọsán ati loru niwaju rẹ.
2 Jẹ ki adura mi ki o wá si iwaju rẹ : dẹ etí rẹ silẹ si igbe mi;
3 Nitori ti ọkkàn mi kún fu ipọnju : ẹmmí mi sì sumọ́ isà okú.
4 A kà mi pẹlu kún awọn ti o sọkalẹ lọ si ihò : emi dabi ọkọnri ti kò ni ipá.
5 Omnira ninu awọn okú, bi awọn ẹni pipa ti o dubulẹ ni isà okú, ẹniti iwọ kò ranti mọ́ : a sì ke wọn kuro nipa ọwọ́ rẹ.
6 Iwọ ti fi mi le ibi isalẹ ti o jìn julọ, ninu òkunkun, ninu ọgbọn.
7 Ibinu rẹ lẹ̀ mọ́ mi lara kikan, iwọ sì ti fi riru omi rẹ gbogbo ba mi ja.
8 Iwọ ti mu awọn ojulumọ̀ mi jina si mi; iwọ sì sọ mi di irira si wọn : a sé mi mọ́, emi kò le jade.
9 Oju mi nkãnu nipa ipọnju : Jehofa, emi ti npè ọ lojojumọ, emi sì ti nawọ́ mi si ọ.

Digitized by Google

10 Iwọ o fi iṣẹ́ iyanu hàn fu awọn okú bi? awọn okú yio ha dide ki o sì ma yìn ọ bi?
11 A o ha fi iṣeun-ifẹ́ rẹ hàn ni isà okú bi? tabi otitọ rẹ ninu iparun?
12 A ha le mọ iṣẹ́ iyanu rẹ li òkunkun bi? ati ododo rẹ ni ilẹ igbagbé?
13 Ṣugbọn iwọ ni mo kigbe si, JEHOFA; ati ni kutukutu owurọ li adura mi yio ṣaju rẹ.
14 JEHOFA, ẽṣe ti iwọ fi ṣa ọkkàn mi tì? ẽṣe ti iwọ fi pa oju rẹ mọ́ kuro lọdọ mi?
15 Iṣẹ́ nṣẹ mi, emi mura ati kú lati igba ewe mi wá: nigbati ẹ̀ru rẹ ba mbà mi, emi di gbere-gbere.
16 Ifẹju ibinu rẹ gùn ori mi; ìbẹru rẹ ti ke mi kuro.
17 Nwọn wá yi mi ká li ọjọ gbogbo bi omi; nwọn yi mi ká kiri tan.
18 Olufẹ ati ọrẹ́ ni iwọ mu jina si mi, ati awọn ojulumọ́ mi sinu òkunkun.

ALẸ IJỌ. 17.

PSALMU 89.

EMI o ma kọrin ãnu JEHOFA lailai: ẹnu mi li emi o ma fi fi otitọ rẹ hàn lati iran-diran.
2 Nitori ti emi ti wipe, A o gbé ãnu ró soke lailai: otitọ rẹ ni iwọ o gbé kalẹ li ọrun tikara rẹ.
3 Emi ti bá ẹni ayanfẹ mi da majẹmu, emi ti bura fu Dafidi iranṣẹ mi,
4 Irú-ọmmọ rẹ li emi o gbé kalẹ lailai, emi o sì ma gbé itẹ́ rẹ ró lati iran-diran.
5 Ọrun yio sì ma yìn iṣẹ́ iyanu rẹ, JEHOFA: otitọ pẹlu ni ijọ awọn enia mimọ́ rẹ.
6 Nitori pe, tali o wà li ọrun ti a le fi wé JEHOFA? tani ninu awọn ọmmọkọnri alagbara, ti a le fi wé JEHOFA?

Digitized by Google

7 Ọlọrun li o ni ìbẹ̀ru gidigidi ni ijọ awọn enia mímọ́, o sì ni ibuyìn-fu lati ọdọ gbogbo awọn ti o yi i ká.

8 Jehofa Ọlọrun awọn ọmmọ ogun, tani Jehofa alagbara bi iwọ? tabi bi otitọ rẹ ti o yi ọ ká?

9 Iwọ li o jọba ibinu ti okun : nigbati riru omi rẹ̀ dide, iwọ mu u pa rọrọ.

10 Iwọ li o ti ya Rahabu pẹrẹ-pẹrẹ, bi ẹni ti a pa ; iwọ ti fi apa ọwọ́ agbara rẹ tú awọn ọtá rẹ ká.

11 Awọn ọrun ni ti rẹ, ilẹ aiye pẹlu ni ti rẹ : aiye ati ẹkun rẹ̀, iwọ li o ti ṣe ipilẹ wọn.

12 Ariwa ati gusù iwọ li o ti dá wọn : Taboru ati Hermon yio ma yọ̀ li orukọ rẹ.

13 Iwọ li apa agbara : agbara li ọwọ́ rẹ, giga li ọwọ́ ọtún rẹ.

14 Otitọ ati idajọ́ ni ibujoko itẹ́ rẹ : ãnu ati otitọ ni yio ma lọ siwaju rẹ.

15 Ibukún ni fu awọn enia ti o mọ̀ ohùn ayọ̀ ni : Jehofa, nwọn o ma rìn ni imọlẹ oju rẹ.

16 Li orukọ rẹ ni nwọn o ma yọ̀ li ọjọ gbogbo : ati ninu ododo rẹ li a o ma gbé wọn leke.

17 Nitori iwọ li ogo agbara wọn : ati ninu ore oju-rere rẹ li a o gbé iwo wa soke.

18 Nitori Jehofa li àbo wa; Ẹni Mímọ́ Israeli li ọba wa.

19 Nigbana ni iwọ sọ li oju iran fu ẹni mímọ́ rẹ, o sì wipe, Emi ti gbé iranlọwọ́ rù ẹnikan alagbara ; emi ti gbé ẹnikan leke ti a yàn ninu awọn enia.

20 Emi ti ri Dafidi iranṣẹ mi; oróro mi mímọ́ ni mo ta si i lori :

21 Pẹlu ẹniti a o fi ọwọ́ mi le ilẹ : apa mi pẹlu yio mu u li ara le.

Digitized by Google

22 Ǫtá kì yio bère lǫdǫ rẹ̀; bẹ̃ni awǫn ǫmmǫ ìwa-buburu kì yio pǫ́n ǫ loju.
23 Emi o sì lù awǫn ǫtá rẹ̀ bǫlẹ niwaju rẹ̀, emi o sì yǫ awǫn ti o korira rẹ̀ lẹnu.
24 Ṣugbǫn otitǫ mi ati ãnu mi yio wà pẹlu rẹ̀ : ati li orukǫ mi li a o gbé iwo rẹ̀ soke.
25 Emi o sì gbé ǫwǫ́ rẹ̀ le okun, ati ǫwǫ́ ǫtún rẹ̀ le awǫn odò nla ni.
26 On yio kigbe pè mi pe, Iwǫ ni babba mi, Ǫlǫrun mi, ati apatta igbala mi.
27 Emi o sì mu u ṣe ǫmmǫ akǫbi mi, gajù awǫn ǫbba ti ilẹ aiye lǫ.
28 Ãnu mi li emi o pamǫ́ fu u lailai, ati majẹmu mi yio sì bá a duro ṣinṣin.
29 Irú-ǫmmǫ rẹ̀ pẹlu li emi o mu pẹ titi, ati itẹ́ rẹ̀ bi ǫjǫ ǫrun.
30 Bi awǫn ǫmmǫ rẹ̀ ba kǫ̀ ofin mi silẹ, ti nwǫn kò sì rìn nipa idajǫ́ mi;
31 Bi nwǫn ba yí aṣẹ mi, ti nwǫn kò sì pa ofin mi mǫ́.
32 Nigbana li emi o fi ǫgǫ bẹ̀ irekǫja wǫn wò, ati ẹ̀ṣẹ wǫn pẹlu ìna.
33 Ṣugbǫn iṣeun-ifẹ́ mi li emi kì yio gbà lǫwǫ́ rẹ̀ patapata, bẹ̃li emi kì yio jẹ ki otitǫ mi ki o yẹ̀.
34 Majẹmu mi li emi kì yio ya, bẹ̃li emi kì yio yi ohun ti o ti ète mi jade pada,
35 Lẹrikan ni mo ti fi ìwa-mimǫ́ mi bura pe, emi kì yio purǫ́ fu Dafidi.
36 Irú-ǫmmǫ rẹ̀ yio duro titi lailai, ati itẹ́ rẹ̀ bi õrùn niwaju mi.
37 A o fi idi rẹ̀ mulẹ lailai bi oṣupa, ati bi ẹlẹ̃ri otitǫ li ǫrun.
38 Ṣugbǫn iwǫ ti ṣa-tì iwǫ sì korira, iwǫ ti binu si ẹni atorórosi rẹ̀.
39 Iwǫ ti sǫ majẹmu iranṣẹ rẹ̀ di ofo : iwǫ ti sǫ ade rẹ̀ di alaìmǫ nipa ifi-wǫ́ ilẹ rẹ̀.

Digitized by Google

40 Iwọ ti fà ọgbà rẹ gbogbo ya; iwọ ti mu ibi agbara rẹ di iparun.
41 Gbogbo awọn ẹniti nkọja lọ li ọna mbà a jẹ: on sì dì ẹgan fu awọn aladugbo rẹ.
42 Iwọ ti gbé ọwọ ọtún ti awọn ọtá rẹ soke; iwọ mu gbogbo awọn ọtá rẹ yọ.
43 Iwọ sì ti yi oju idà rẹ pada pẹlu, iwọ kò sì fifu u lati duro li oju ogun.
44 Iwọ ti mu ogo rẹ tẹ, iwọ sì wó itẹ rẹ silẹ ilẹ.
45 Ọjọ ewe rẹ iwọ li o ke kuru: iwọ fi ìtiju bò o.
46 Yio ti pẹ to, JEHOFA? iwọ yio pa ara rẹ mọ lailai? ibinu rẹ yio ha jó bi iná bi?
47 Ranti bi ọjọ mi ti kuru to: Nitorina iwọ ha da gbogbo awọn enia lasan?
48 Ọkọnri ewo li o wà lãye, ti kì yio ri ikú? on yio gbà ọkàn rẹ lọwọ isà okú?
49 OLUWA, nibo ni iṣeun-ifẹ rẹ atijọ wà, ti iwọ bura fu Dafidi ninu otitọ rẹ?
50 OLUWA, ranti ẹgan awọn iranṣẹ rẹ; bi emi ti ngbà ẹgan gbogbo awọn alagbara enia li àiya mi;
51 Ti awọn ọtá rẹ fi kẹgàn, JEHOFA: eyi ti nwọn fi ngàn ipasẹ ẹni atorórosi rẹ.
52 Olubukún ni JEHOFA si i titi lailai. Amin ati Amin.

OWURỌ IJỌ. 18.

PSALMU 90.

OLUWA, iwọ li o ti nṣe ibujoko wa lati iran-diran.
2 Ki a to bí awọn òke nla, ati ki iwọ ki o to dá ilẹ on aiye, ani lati aiye-raiye, iwọ li Ọlọrun.

Digitized by Google

3 Iwọ sọ ẹnia di ibajẹ; iwọ sì wipe, Ẹ tũn pada wá, ẹnyin awọn ọmmọ enia.
4 Nitori pe igbati ẹgbẹrun ọdún ba kọja li oju rẹ bi aná li o ri, ati bi igba iṣọ kan li oru.
5 Iwọ nkó wọn lọ bi ẹnipe ni ṣiṣàn-omi; nwọn dabi orun; ni kutukutu nwọn dabi koriko ti o dàgba soke.
6 Ni kutukutu o li àwọ lara, o sì dàgba soke, li aṣalẹ a ke e lulẹ, o sì rọ.
7 Nitori awa di egbé nipa ibinu rẹ, ati nipa ibinu rẹ ara kò rọ wa.
8 Iwọ ti gbé ẹṣẹ wa kalẹ niwaju rẹ, ẹṣẹ ikọkọ wa mbẹ ninu imọlẹ iwaju rẹ.
9 Nitori ti ọjọ wa gbogbo nyipo lọ ninu ibinu rẹ: awa nlò ọjọ wa bi alá ti a nrò.
10 Adọrin ọdún li ọjọ awọn ọdún wa; bi o sì ṣepe nipa ti agbara bi nwọn ba to ọgọrin ọdún, agbara wọn lãlã on ibinujẹ ni; nitori nisisiyi ni yio ke kuro, awa a sì fò lọ.
11 Tali o mọ agbara ibinu rẹ? gẹgẹ bi ẹru rẹ bẽni ibinu rẹ.
12 Bẽni ki iwọ ki o kọ wa lati ma kaye ọjọ wa, ki awa ki o le fi ọkkàn wa sipa ọgbọn.
13 Pada, JEHOFA, yio ti pẹ to? ronupiwada nitori ti awọn ọmmọ ọdọ rẹ.
14 Fi ãnu rẹ tẹ wa li ọrùn ni kutukutu; ki awa ki o le ma yọ ati ki inu wa ki o le ma dùn li ọjọ wa gbogbo.
15 Mu inu wa dùn bi iye ọjọ ti iwọ pọn wa loju, ati iye ọdún ti awa ti nri buburu.
16 Jẹ ki iṣẹ rẹ ki o hàn si awọn ọmmọ ọdọ rẹ, ati ogo rẹ si awọn ọmmọ wọn.
17 Jẹ ki ẹwà ti OLUWA Ọlọrun wa ki o sì mbẹ lara wa: ki iwọ ki o sì fi idi iṣẹ ọwọ wa mulẹ lara wa; bẽni iṣẹ ọwọ wa ni ki iwọ ki o fi idi rẹ mulẹ.

Digitized by Google

Psalmu 91.

ENITI o joko ni ibi ìkọ́kọ́ ti ọgá-ogo ni yio ma gbé abbẹ́ ojiji ti Olodumare.

2 Èmi o wi nipa ti Ọlọ́run pe, On li àbo ati odi lagbara mi : Ọlọ́run mi; on li emi o gbẹ́kẹ̀le.

3 Nitõtọ́ on yio gbà ọ ninu ikẹ́kun ti awọn pẹ̀iyẹ́-pẹ̀iyẹ́, ati ninu ajakalẹ̀ arun buburu.

4 Yio fi iyẹ́ rẹ̀ bò ọ, abbẹ́ iyẹ́ apa rẹ̀ ni iwọ o sì gbẹ́kẹ̀le : otitọ́ rẹ̀ ni yio ṣe asà ati apatta rẹ̀.

5 Iwọ kì yio bẹ̀ru nitori ẹ̀ru oru; tabi fu ọfà ti nfò li ọ̀sán;

6 Tabi fu ajakalẹ̀ arun ti nrìn kiri li òkunkun; tabi fu iparun ti nrun-ni li ọ̀sán gangan.

7 Ẹgbẹ̀run yio ṣubu li ẹgbẹ̀ rẹ̀, ati ẹgbarun li apa ọ̀tún rẹ̀; ṣugbọn kì yio sumọ́ ọdọ́ rẹ̀.

8 Kìki oju rẹ̀ ni iwọ o ma fi ri ti o sì ma fi wò èrè awọn enia buburu.

9 Nitori ti iwọ fi Jehofa ti ṣe àbo mi, ani ọgá-ogo, ṣe ibujoko rẹ̀;

10 Buburu kan kì yio ṣubu lù ọ, bẹ̃li arunkarun kì yio sumọ́ ile rẹ̀.

11 Nitori ti yio fi aṣẹ̀ fu awọn angeli rẹ̀ nitori rẹ̀, lati pa ọ mọ́ nipa ọ̀na rẹ̀ gbogbo.

12 Nwọn o gbé ọ soke li ọwọ́ wọn, ki iwọ ki o má ba fi ẹsẹ̀ rẹ̀ ṣankuta.

13 Iwọ o tẹ̀ kiniu ati pamọlẹ̀ : ẹgbọrọ kiniu ati ejò ni iwọ o fi ẹsẹ̀ tẹ̀-mọlẹ̀.

14 Nitori ti o fẹ̀ ifẹ́ rẹ̀ si mi, nitorina li emi o ṣe gbà a : emi o gbé e leke, nitori ti o mọ̀ orukọ́ mi,

15 On yio pè orukọ́ mi, emi o sì da a lohùn : emi o pẹ̀lu rẹ̀ ninu ipọnju, emi o gbà a, emi o sì bù ọlá fu u.

Digitized by Google

16 Ẹmmí gigun li emi o fi tẹ ẹ lọrùn, emi ọ sì fi igbala mi hàn a.

Psalmu 92.

OHUN rere ni lati ma fi ọpẹ fu Jehofa, ati lati ma kọnrin si orukọ rẹ, ọgá-ogo :
2 Lati ma fi iṣeun-ifẹ rẹ hàn li orowurọ, ati otitọ rẹ li alalẹ,
3 Lara ohun ọnà orin olukun mẹwa, ati lara èlo orin mimọ; lara dùru pẹlu iró ti o ni ironu.
4 Nitori iwọ, Jehofa, li o ti mu mi yọ nipa iṣẹ rẹ : emi o ma ṣe ileri nipa iṣẹ ọwọ rẹ.
5 Jehofa, iṣẹ rẹ ti tobi to! ìro inu rẹ jinlẹ gidigidi.
6 Ẹranko enia kò mọ; bẹ̃li oyé eyi kò yé aṣiwere enia.
7 Nigbati awọn enia buburu ba rú bi koriko, ati igbati gbogbo awọn oniṣẹ èṣẹ ba ngberu : ki nwọn ki o le run lailai ni :
8 Ṣugbọn iwọ, Jehofa, li ọgá-ogo titi lai.
9 Sá wò o, awọn ọtá rẹ, Jehofa, sá wò o, awọn ọtá rẹ yio ṣegbé; gbogbo awọn oniṣẹ èṣẹ li a o tuká.
10 Ṣugbọn iwo mi ni iwọ o gbéga bi iwo agbanrere : oróro titun li a o ta si mi lori.
11 Oju mi pẹlu yio ri ifẹ mi lara awọn ọtá mi, etí mi yio sì ma gbọ ifẹ mi si awọn enia buburu ti o dide si mi.
12 Awọn olododo yio gbà bi igi ọpẹ : yio dàgba bi igi opepe ti Lebanon.
13 Awọn ẹniti a gbìn ni ile Jehofa yio gbà ni agbala Ọlọrun wa.
14 Nwọn o ma so eso sibẹ ninu ogbó wọn; nwọn o sanra, nwọn a ma tutù nini;
15 Lati fi hàn pe, iduro ṣinṣin ni Jehofa : on li apatta mi, kò sì si alṣodododo kan ninu rẹ.

Digitized by Google

ALẸ IJỌ. 18.

PSALMU 93.

JEHOFA jọbba, ọllá-nla li o wọ̀ li aṣọ; agbara ni JEHOFA wọ̀ li aṣọ, ninu eyi ti o fi di ara rẹ̀ li amure : a sì fi idi aiye mulẹ, ti kì yio fi le yi.

2 Ni igba atijọ li a ti fi idi itẹ́ rẹ kalẹ, ati aiye-raiye ni iwọ.

3 Awọn ìṣan-omi gbé ohùn wọn soke, JEHOFA, awọn ìṣan-omi gbé ohùn wọn soke; awọn ìṣan-omi gbé riru omi wọn soke.

4 JEHOFA li oke o lagbara jù ariwo omi pupọ̀ lọ, ani jù riru nla omi, jù agbara riru omi okun lọ.

5 Ẹrí rẹ daniloju : ìwa-mimọ́ li o yẹ ile rẹ lailai, JEHOFA.

PSALMU 94.

JEHOFA Ọlọrun ẹsan; Ọlọrun ẹsan, tàn imọlẹ.

2 Gbé ara rẹ soke, iwọ onidajọ aiye : san ẹsan fu awọn agberaga.

3 JEHOFA, yio ti pẹ to ti awọn enia buburu, yio ti pẹ to ti awọn enia buburu yio fi ma ṣe ileri?

4 Nwọn o ti ma sọ̀rọ ohun lile pẹ to? ti gbogbo awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ yio fi ma ṣe ileri ara wọn.

5 JEHOFA, nwọn fọ́ awọn enia rẹ tútu, nwọn sì nyọ awọn enia ilẹ rẹ lẹnu.

6 Nwọn pa awọn opó ati alejò, nwọn sì pa awọn ọmmọ alaìni-babba.

7 Ṣugbọn nwọn wipe, JEHOFA kì yio ri i, bẽli Ọlọrun Jakobu kì yio kà a si.

Digitized by Google

8 Ki oyé ki o yé nyin, ẹnyin bi ẹranko ninu awọn enia: ati ẹnyin aṣiwere, nigbawo li ẹnyin o gbọ́n?
9 Ẹniti o gbìn etí, o le ṣe àlgbọ́? ẹniti o da oju, o le ṣe àrina?
10 Ẹniti n-nà awọn keferi, o le ṣe alaìṣe olutọ́? ẹniti nkọ́ enia ni ìmọ, o le ṣe alaìmọ̀?
11 Jehofa mọ̀ awọn ìro inu enia, pe asan ni nwọn.
12 Ibukún li enia na ẹniti iwọ nà, Jehofa, ti iwọ sì kọ́ ọ lati inu ofin rẹ wá;
13 Ki iwọ ki o le fu u ni isimi kuro li ọjọ́ ipọnju, titi a o fi wà ihò silẹ fu awọn enia buburu.
14 Nitori pe Jehofa kì yio ṣa awọn enia rẹ̀ tì, bẹ̃ni kì yio kọ̀ awọn enia ilẹ rẹ̀ silẹ.
15 Ṣugbọn idajọ́ yio pada si ododo: ati gbogbo awọn ọlọkàn diduro ni yio sì ma tọ̀ ọ lẹhin.
16 Tani yio dide si awọn oluṣe buburu fu mi? tabi tani yio dide soke si awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ fu mi?
17 Bikoṣe bi Jehofa ti ṣe oluranlọwọ mi, ọkàn mi fẹrẹ joko ni idakẹ.
18 Nigbati mo wipe, Ẹsẹ mi yọ̀; Jehofa, ãnu rẹ gbé mi soke.
19 Ninu ọpọlọpọ ìro inu mi ninu mi, itunu rẹ li o nmu inu mi dùn.
20 Itẹ́ ẹ̀ṣẹ ha le bá ọ kẹgbẹ pọ̀, ti o nfi ofin dì mọ́ ìwa ìka?
21 Nwọn kó ara wọn jọ pọ̀ si ọkàn awọn olododo, nwọn sì da ẹ̀jẹ alaìṣẹ lẹbi.
22 Ṣugbọn Jehofa li àbo mi; Ọlọrun mi sì li apatta àbo mi.
23 On yio sì mu ẹ̀ṣẹ wọn bọ̀ sori ara wọn, yio sì ke wọn kuro ninu ìwa-buburu wọn; Jehofa Ọlọrun wa yio ke wọn kuro.

Digitized by Google

OWURỌ IJỌ. 19.

PSALMU 95.

ENYIN wá, ẹ jẹ ki a kọnrin si JEHOFA : ẹ jẹ ki a hó ihó ayọ̀ si apatta igbala wa.

2 Ẹnyin jẹ ki a fi ọpẹ́ wá si iwaju rẹ̀, ki a sì fi orin mimọ́ hó ihó ayọ̀ si ọdọ rẹ̀.

3 Nitori JEHOFA Ọlọrun ti o tobi ni, ati Ọbba ti o tobi jù gbogbo awọn ọlọrun lọ.

4 Ni ikawọ ẹniti ibi ọgbọn ilẹ wà : iga òke nla ni ti rẹ̀ pẹlu.

5 Ti rẹ̀ li okun, on li o sì da a : ọwọ́ rẹ̀ li o sì da iyangbẹ ilẹ.

6 Ẹnyin wá, ẹ jẹ ki a wolẹ ki a tẹriba : ẹ jẹ ki a kunlẹ niwaju JEHOFA Ẹlẹda wa.

7 Nitori on li Ọlọrun wa ; awa sì li awọn enia papa rẹ̀, ati agutan ọwọ́ rẹ̀. Loni bi ẹnyin ba nfẹ gbọ́ ohùn rẹ̀,

8 Ẹ má sé àiya nyin le, bi igba imunibinu, ati bi ọjọ idanwò li aganjù :

9 Nigbati awọn babba nyin dan mi wò, ti nwọn mọ̀ mi, ti nwọn sì ri iṣẹ́ mi.

10 Ogoji ọdún tọ̀tọ ni inu mi fi bajẹ si iran yi, mo ni, Enia li o nṣìna li àiya wọn, nwọn kò sì mọ̀ ipa ọna mi :

11 Awọn ẹniti mo sì bura fu ni ibinu mi pe, nwọn kì yio sì wọ̀ ibi isimi mi.

PSALMU 96.

E KỌN ORIN titun si JEHOFA : ẹ kọnrin si JEHOFA gbogbo ilẹ aiye.

2 Ẹ kọnrin si JEHOFA, fi ibukún fu orukọ rẹ̀ ; ẹ ma fi igbala rẹ̀ hàn lati ọjọ de ọjọ.

3 Sọrọ ogo rẹ̀ ninu awọn keferi, ati iṣẹ́ iyanu rẹ̀ ninu gbogbo awọn enia.

Digitized by Google

4 Nitori ti JEHOFA tobi, o sì pọ̀ju lati ma yìn : on li o ni ìbẹ̀ru jù gbogbo awọn ọlọrun lọ.

5 Nitori pe gbogbo awọn ọlọrun ti orilẹ èdè ere ni nwọn : ṣugbọn JEHOFA li o da awọn ọrun.

6 Ọlá ati ọlá-nla li o wà niwaju rẹ̀ : ipá ati ẹwà mbẹ ninu ibi mímọ́ rẹ̀.

7 Ẹ fi fu JEHOFA, ẹnyin ibatan enia, ẹ fi ogo ati ipá fu JEHOFA.

8 Ẹ fi ogo ti o yẹ fu orukọ JEHOFA : mu ọrẹ wá, ki ẹ sì wá si agbala rẹ̀.

9 Ẹ ma sìn JEHOFA ninu ẹwà ìwa-mímọ́ : ẹ bẹ̀ru niwaju rẹ̀, gbogbo ilẹ aiye.

10 Ẹ wi ninu awọn keferi pe, JEHOFA jọba : a o sì fi idi aiye mulẹ ti kì yio le yi : on yio fi ododo ṣe idajọ́ awọn enia.

11 Jẹ ki awọn ọrun ki o yọ̀, jẹ ki inu ilẹ aiye ki o dùn ; jẹ ki okun ki o ma hó pẹlu ikún rẹ̀.

12 Jẹ ki igbẹ́ ki o kún fu ayọ̀, ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu rẹ̀ : nigbana ni gbogbo igi igbó yio ma yọ̀.

13 Niwaju JEHOFA : nitori ti mbọ̀wá, nitori ti mbọ̀wá ṣe idajọ́ ilẹ aiye : yio fi ododo ṣe idajọ́ aiye, ati ti awọn enia ni yio fi otitọ rẹ̀ ṣe.

PSALMU 97.

JEHOFA jọba ; ki ilẹ aiye ki o yọ̀ ; jẹ ki inu ọ̀pọ̀lọpọ̀ erekuṣu ki o dùn nitori rẹ̀.

2 Awọ-sanma ati òkunkun yi i ká : ododo ati idajọ́ ni ibujoko itẹ́ rẹ̀.

3 Iná kan ṣaju rẹ̀, o sì jó awọn ọtá rẹ̀ yiká kiri.

4 Manamana rẹ̀ kọ́ imọlẹ̀ si aiye : ilẹ aiye ri i, o wa-rìri.

Digitized by Google

5 Awọn òke nyọ́ bi ida niwaju JEHOFA, niwaju OLUWA ti gbogbo ilẹ aiye.
6 Awọn ọrun fi ododo rẹ̀ hàn, gbogbo awọn enia sì ri ogo rẹ̀.
7 Idamu ni gbogbo awọn ti nsìn ere fifin, ẹniti nfi ere ṣe ileri ara wọn : ẹ ma sìn i ẹnyin gbogbo awọn ọlọrun.
8 Sion gbọ́, inu rẹ̀ sì dùn ; awọn ọmmọbiri Juda sì yọ̀, JEHOFA, nitori idajọ́ rẹ.
9 Nitori pe iwọ, JEHOFA, li o ga jù gbogbo aiye lọ : iwọ li a gbéga soke jù gbogbo awọn ọlọrun.
10 Ẹnyin ti o fẹ JEHOFA, ẹ korira ibi : o pa ọkàn awọn enia mimọ́ rẹ̀ mọ́ ; o gbà wọn li ọwọ́ awọn enia buburu.
11 Imọlẹ nru soke fu olododo, ati inu didùn fu awọn alaiya diduro.
12 Ẹ yọ̀ ni ti JEHOFA, ẹnyin olododo ; ki ẹ sì ma dupẹ ni iranti ìwa-mimọ́ rẹ̀.

ALẸ IJỌ. 19.

PSALMU 98.

EKỌN ORIN titun si JEHOFA ; nitori ti o ti ṣe ohun iyanu : ọwọ́ ọtún rẹ̀, ati apa rẹ̀ mimọ́, on li o ti fi ṣẹgun fu ara rẹ̀.
2 JEHOFA ti fi igbala rẹ̀ hàn : ododo rẹ̀ li o ti fi hàn nigbangba li oju awọn keferi.
3 O ti ranti ãnu rẹ̀ ati otitọ rẹ̀ si awọn ara ile Israeli : gbogbo opin ilẹ aiye ti ri igbala Ọlọrun wa.
4 Ẹ hó ihó ayọ̀ si JEHOFA, gbogbo ilẹ aiye : ẹ hó yè, ẹ yọ̀, ki ẹ sì ma kọrin iyìn.
5 Ẹ ma fi dùru kọrin si JEHOFA ; ati dùru pẹlu ohùn orin mimọ́.

Digitized by Google

6 Pẹlu ìpe ati ohùn fère, ẹ hó ihó ayọ̀ niwaju JEHOFA, Ọbba.
7 Jẹ ki okun ki o ma hó pẹlu ikún rẹ̀; aiye, ati awọn ti mbẹ ninu wọn.
8 Jẹ ki awọn odò ki o ma ṣapẹ : ki awọn òke ki o ma ṣe ajọyọ̀.
9 Niwaju JEHOFA; nitori ti mbọwá lati ṣe idajọ́ aiye : pẹlu ododo ni yio fi ṣe idajọ́ aiye, ati awọn enia li alṣegbe.

PSALMU 99.

JEHOFA jọbba; jẹ ki awọn enia ki o wárìri : o joko larin awọn kerubu; ki ilẹ aiye ki o ta gbọngbọn.
2 JEHOFA tobi ni Sion; o sì ga jù gbogbo awọn enia lọ.
3 Ki nwọn ki o yìn orukọ rẹ ti o pọ̀ ti o sì li èru; mimọ́ ni.
4 Agbara ọbba fẹ idajọ́ pẹlu; iwọ fi idi alṣegbe mulẹ, iwọ nṣe idajọ́ ati ododo ni Jakobu.
5 Ẹ gbé JEHOFA Ọlọrun wa ga, ki ẹ sì foribalẹ nibi apoti itisẹ rẹ̀; mimọ́ ni.
6 Mose ati Aaron ninu awọn alufa rẹ̀, ati Samueli ninu awọn ti npè orukọ rẹ̀; nwọn pè orukọ JEHOFA, o sì da wọn lohùn.
7 O ba wọn sọ̀rọ ninu ọwọ̀n awọ-sanma : nwọn pa ẹrí rẹ̀ mọ́, ati ìlana ti o fifu wọn.
8 Iwọ da wọn lohùn, JEHOFA Ọlọrun wa : iwọ li Ọlọrun ti o darijì wọn, bi o tilẹ ṣepe iwọ a ma san ẹsan ìhumọ wọn.
9 Ẹ gbé JEHOFA Ọlọrun wa ga, ki ẹ sì ma sìn nibi òke mimọ́ rẹ̀; nitori JEHOFA Ọlọrun wa mimọ́ ni.

Digitized by Google

Psalmu 100.

EHÓ ihó ayò si Jehofa, ẹnyin ilẹ aiye gbogbo.
2 Ẹ fi ayò sìn Jehofa : ẹ wá ti ẹnyin ti orin si iwaju rẹ̀.
3 Ki ẹnyin ki o mọ̀ pe Jehofa on li Ọlọrun : on li o da wa, kì ise awa tikara wa; awa li awọn enia rẹ̀, ati agutan papa rẹ̀.
4 Ẹ lọ si ẹnu ọ̀na rẹ̀ ti ẹnyin ti ọpẹ́, ati si afin rẹ̀ ti ẹnyin ti iyìn : ẹ ma dupẹ̀ fu u, ki ẹ sì ma fi ibukún fu orukọ rẹ̀.
5 Nitori ti Jehofa pò li ore; ãnu rẹ̀ kò nipẹkun; ati otitọ rẹ̀ lati iran-diran.

Psalmu 101.

EMI o kọnrin ãnu ati ti idajó : Jehofa, si iwọ li emi o ma kọnrin.
2 Emi o ma rìn ìrin mi pẹlu ọgbọ́n li ọ̀na ti o pé. Nigbawo ni iwọ o tọ̀ mi wá? emi o ma rìn ninu ile mi pẹlu àiya pipé.
3 Emi kì yio gbé ohun buburu siwaju oju mi : emi korira iṣẹ́ awọn ti nyipada si apakan; kì yio fi ara mọ́ mi.
4 Àiya ṣiṣo yio kuro lọdọ mi : emi kì yio mọ̀ enia buburu.
5 Ẹnikẹni ti o ba kẹgàn ẹnikeji rẹ̀ ni ìkọkọ, on li emi o ke kuro : ẹniti o li ọwọ́ giga ati igberaga àiya, on li emi kì yio jẹ fu.
6 Oju mi yio wà lara awọn olõtọ ti ilẹ na, ki nwọn ki o le ma ba mi gbé : ẹniti o ba nrìn li ọ̀na pipé, on ni yio ma sìn mi.
7 Ẹniti o ba nṣe ẹ̀tan kì yio gbé inu ile mi : ẹniti o ba nṣeke kì yio duro ni iwaju mi.
8 Lati ipilẹṣẹ̀ li emi o run gbogbo awọn

Digitized by Google

enia buburu ti ilẹ na; ki emi ki o le ke gbogbo awọn oluṣe buburu kuro ni ilu-nla ti JEHOFA.

OWURỌ IJỌ. 20.

PSALMU 102.

GBỌ adura mi, JEHOFA, ki o sì jẹ ki igbe mi ki o ma wá sọdọ rẹ.

2 Má ṣe pa oju rẹ mọ́ kuro lara mi li ọjọ ti emi wà ninu ipọnju; dẹ etí rẹ si mi: li ọjọ ti mo ba pè da mi lohùn lọ́gan.

3 Nitori ti ọjọ mi run bi ẽfin, egungun mi sì jóna bi àro.

4 Àiya mi lù, o sì rọ bi koriko; bẹ̃ni mo gbagbé lati jẹ onjẹ mi.

5 Nitori ohùn ti irora mi, egungun mi lẹ mọ́ ẹran ara mi.

6 Emi dabi ẹïyẹ nla ni ijù: emi dabi owiwí aṣalẹ.

7 Emi nṣọra, emi dabi ologoṣẹ nikan li ori ile.

8 Awọn ọtá mi ngàn mi li ọjọ gbogbo; ati awọn ti nṣe ikanra si mi, nwọn bura si mi.

9 Emi sá jẹ ẽru bi onjẹ, emi sì da ohun mimu mi pọ̀ pẹlu omije,

10 Nitori ikan-nu ati ibinu rẹ; nitori iwọ ti gbé mi soke, iwọ sì sọ mi kalẹ.

11 Ọjọ mi dabi ojiji ti o nfà sẹhin; emi sì nrọ bi koriko.

12 Ṣugbọn iwọ, JEHOFA, ni yio duro lailai; ati iranti rẹ de awọn iran gbogbo.

13 Iwọ o dide, iwọ o ṣãnu fu Sion: nitori igba ati ṣe oju-rere si i, nitõtọ, akokò igba na de.

Digitized by Google

14 Nitori ti awọn iranṣẹ rẹ ṣe inu didùn si awọn okuta rẹ̀, nwọn sì fẹ erupẹ̀ rẹ̀.
15 Bẹ̀li awọn keferi yio ma bẹ̀ru orukọ JEHOFA, ati gbogbo awọn ọba ilẹ aiye yio ma bẹ̀ru ogo rẹ.
16 Nigbati JEHOFA, yio gbé Sion ró, yio yọ ninu ogo rẹ̀.
17 Yio juba adura ti awọn alàìni, kì yio sì gàn adura wọn.
18 Eyi li a o kọ fu iran ti mbọ̀ : ati awọn enia ti a o da yio ma yìn JEHOFA.
19 Nitori ti o ti wò ilẹ lati oke ibi mimọ́ rẹ̀ wá; lati ọrun wá ni JEHOFA bojuwò ilẹ aiye;
20 Lati gbọ́ irora ti ara tubu; lati tú awọn ti a yàn si ikú;
21 Lati sọ orukọ JEHOFA ni Sion, ati iyìn rẹ̀ ni Jerusalemu;
22 Nigbati awọn enia pèjọ pọ̀, ati awọn ijọba, lati ma sìn JEHOFA.
23 O fà ipá mi sẹhin li ọ̀na; o mu ọjọ mi kuru.
24 Emi sì wipe, Ọlọrun mi, má ṣe mu mi kuro li agbede-meji ọjọ mi : lati iran-diran gbogbo li ọdún rẹ.
25 Lati igba atijọ ni iwọ ti fi ipilẹ aiye sọlẹ : awọn ọrun sì ni iṣẹ́ ọwọ́ rẹ.
26 Nwọn o ṣegbé, ṣugbọn iwọ o duro : nitõtọ, gbogbo wọn ni yio di ogbó bi aṣọ; bi ẹ̀wu ni iwọ o pàrọ wọn, nwọn o sì pàrọ :
27 Ṣugbọn bakana ni iwọ, ọdún rẹ kò li opin.
28 Awọn ọmmọ ti awọn iranṣẹ rẹ yio duro pẹ, a o sì fi ẹsẹ irú-ọmmọ wọn mulẹ niwaju rẹ.

Digitized by Google

Psalmu 103.

FI ibukún fu Jehofa, iwǫ ǫkkàn mi : ati gbogbo ohun ti o wà ninu mi, fi ibukún fu orukǫ rẹ̀ mimǫ́.

2 Fi ibukún fu Jehofa, iwǫ ǫkkàn mi, má sì ṣe gbagbé gbogbo ore rẹ̀ :

3 Ẹniti o dari gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ jì ǫ ; ẹniti o sì tan gbogbo arun rẹ̀ ;

4 Ẹniti o rà ẹmmí rẹ̀ kuro ninu iparun ; ẹniti o fi iṣeun-ifẹ́ ati iyǫnu de ǫ li ade ;

5 Ẹniti o fi ohun didara tẹ́ ǫ li ẹnu ; bẹ̃ni igba ewe rẹ̀ di ǫtún bi ti idì.

6 Jehofa ṣe ododǫ ati idajǫ́ fu gbogbo awǫn ti anilara.

7 O fi ỳna rẹ̀ hàn fu Mose, iṣe rẹ̀ fu awǫn ǫmmǫ Israeli.

8 Jehofa li alãnu ati olõre, o lǫra ati binu, o sì pỳ li ãnu.

9 On kò baniwi nigba-gbogbo : bẹ̃ni kò pa ibinu rẹ̀ mǫ́ lailai.

10 On kò ṣe si wa nipa ẹ̀ṣẹ̀ wa ; bẹ̃ni kò san a fu wa gẹ̀gẹ̀ bi ẹ̀ṣẹ̀ wa.

11 Nitori pe, bi ǫrun ti ga jù ilẹ̀ lǫ, bẹ̃li ãnu rẹ̀ tobi sipa awǫn ti o bẹ̀ru rẹ̀.

12 Bi ìla-õrùn ti jìna si ìwǫ-õrùn, bẹ̃li o mu irekǫja wa jìna kuro lǫdǫ wa.

13 Bi babba ti ṣe iyǫnu si awǫn ǫmmǫ rẹ̀, bẹ̃li Jehofa ṣe iyǫnu si awǫn ti o bẹ̀ru rẹ̀.

14 Nitori ti o mỳ ara wa ; o ranti pe erupẹ̀ ni wa.

15 Bi o ṣe ti enia ni, ǫjǫ rẹ̀ dabi koriko : bi itaná eweko igbẹ́, bẹ̃li o gbilẹ̀.

16 Nitori ti afẹ́fẹ́ fẹ́ kọja lǫ lori rẹ̀, kò sì mǫ́ ; ibi ti o gbé ti wà kò mỳ ǫ mǫ́.

17 Ṣugbǫn ãnu Jehofa lati aiye-raiye ni

Digitized by Google

lara awọn ti o bèru rẹ̀, ati ododo rẹ̀ lati ọmmọ de ọmmọ;

18 Si irú awọn ti o pa majẹmu rẹ̀ mọ́, ati si awọn ti o ranti ofin rẹ̀ lati ṣe wọn.

19 JEHOFA, ti pèse itẹ́ rẹ̀ ninu awọn ọrun; ijọba rẹ̀ li o sì bori ohun gbogbo;

20 Ẹ fi ibukún fu JEHOFA, ẹnyin awọn angeli rẹ̀, ti o pọ̀ ni ipá, ti nṣe ofin rẹ̀, ti nfi etí si ohùn ọ̀rọ rẹ̀.

21 Ẹ fi ibukún fu JEHOFA, ẹnyin awọn ọmmọ ogun rẹ̀ gbogbo; ẹnyin awọn alufa rẹ̀, ti nṣe ifẹ́ rẹ̀.

22 Ẹ fi ibukún fu JEHOFA, gbogbo awọn iṣẹ́ rẹ̀ ni ibi gbogbo ijọba rẹ̀: fi ibukún fu JEHOFA, iwọ okàn mi.

ALẸ IJỌ. 20.

PSALMU 104.

FI ibukún fu JEHOFA, iwọ ọkàn mi. JEHOFA, Ọlọrun mi, iwọ tobi jọjọ; ọlá ati ọlá-nla ni iwọ wọ̀ li aṣọ.

2 Ẹniti o fi imọlẹ bò ara rẹ̀ bi ẹnipe aṣọ: ẹniti o ta awọn ọrun bi aṣọ tita:

3 Ẹniti o fi ìti ọpá ti àja iyẹwu rẹ̀ le inu omi: ẹniti o ṣe awọ-sanma ni kẹ̀kẹ́ rẹ̀: ẹniti o nrìn lori apa iyẹ́ ti afẹ́fẹ́:

4 Ẹniti o ṣe awọn angeli rẹ̀ li ẹmí; awọn iranṣẹ rẹ̀ li ọwọ́ iná:

5 Ẹniti o fi ipilẹ̀ aiye sọlẹ̀, ki a má le ṣí i nipò pada lailai.

6 Iwọ fi ọgbọn bò o mọlẹ̀ bi aṣọ: awọn omi dide duro ga jù awọn òke nla lọ.

7 Nipa ibawi rẹ̀ nwọn sá; nipa ohùn ãrá rẹ̀ nwọn yara lọ.

Digitized by Google

8 Awọn òke nla nru; awọn afonifoji nsọkalẹ si ibi ti iwọ ti da silẹ fu wọn.
9 Iwọ ti pa àla kan ki nwọn ki o ma le kọja rẹ; ki nwọn ki o ma tún pada lati bò ilẹ aiye mọlẹ.
10 Iwọ rán isun si afonifoji, ti nṣàn larin awọn òke.
11 Awọn ni nfi omi mimu fu awọn ẹranko igbẹ gbogbo : awọn kẹtẹkẹtẹ igbẹ npa ongbẹ wọn.
12 Lẹba wọn li awọn ẹïyẹ oju ọrun yio ni ile wọn, ti nkọnrin larin ọwọ́ igi.
13 O mbomi rin awọn òke lati iyẹwu rẹ wá : iṣẹ́ ọwọ́ rẹ tẹ́ ilẹ aiye lọrùn.
14 O mu koriko dàgba fu ẹran, ati ewebẹ fu ìlo enia : ki o le ma so eso jade lati ilẹ wá;
15 Ati ọti wain ti imu inu enia dùn, ati oróro ti imu oju rẹ dan, ati onjẹ ti imu enia li àiya le.
16 Igi Jehofa kún fu ojẹ, igi opepe Lebanon, ti o ti gbìn;
17 Nibiti awọn ẹïyẹ ntẹ́ itẹ́ wọn : bi o ṣe ti àkọ ni, igi tutù nla ni ile rẹ̀.
18 Awọn òke giga li àbo fu awọn ewurẹ igbẹ́; ati awọn apata fu awọn ehoro.
19 O yàn oṣupa fu akokò : õrùn mọ̀ akokò lwọ rẹ̀.
20 Iwọ ṣe òkunkun, o sì ṣe oru : ninu eyi ti gbogbo ẹranko nrìn ninu igbó.
21 Awọn ẹgbọrọ kiniu ndún si ọdẹ wọn, nwọn sì nwá onjẹ wọn lọwọ́ Ọlọrun.
22 Õrùn là, nwọn kó ara wọn jọ, nwọn dubulẹ ninu ihò wọn.
23 Enia jade lọ si iṣẹ́ rẹ̀ ati si lãlã rẹ̀ titi o fi di aṣalẹ.
24 Jehofa, iṣẹ́ rẹ ti pọ̀ tọ! ninu ọgbọ́n

Digitized by Google

ni iwọ ṣe gbogbo wọn : ilẹ aiye kún fu ọrọ rẹ.

25 Bẽli okun nla ti o ni ibò yi, ninu eyi ti ohun aìniye nrakò, ati ẹran kekere ati nla.

26 Nibẹ li ọkọ nrìn : nibẹ li erinmi ni wà, ti iwọ da lati ma ṣe ariya ninu rẹ.

27 Gbogbo nwọnyi li o duro tì ọ; ki iwọ ki o le ma fu wọn li onjẹ wọn li akokò.

28 Eyi ti iwọ fifu wọn ni nwọn nkó : iwọ ṣí ọwọ́ rẹ, nwọn sì kún fu ohun rere.

29 Iwọ pa oju rẹ mọ́, ara kò rọ wọn : iwọ gbà ẹmmí wọn, nwọn kú, nwọn sì pada di erupẹ wọn.

30 Iwọ rán ẹmmi rẹ jade, a sì da wọn : iwọ sì sọ oju ilẹ aiye di ọtún.

31 Ogo JEHOFA yio wà lailai : JEHOFA o yọ̀ ni iṣẹ́ rẹ̀.

32 O bojuwò ilẹ aiye, o sì wa-rìrì : o fi ọwọ́ kàn awọn òke, nwọn sì ru ẽfin.

33 Emi o ma kọnrin si JEHOFA niwọn bi emi o ti wà pẹ to : emi o ma kọnrin iyìn si Ọlọrun mi niwọn igbati mo ni ìwa mi.

34 Iṣaro mi nipa ti rẹ̀ yio dùn : inu mi yio ma dùn ni ti JEHOFA.

35 Jẹ ki awọn enia buburu ki o run kuro ni ilẹ aiye, ki awọn enia buburu ki o má sì mọ́. Fi ibukún fu JEHOFA, iwọ okkàn mi. Ẹ fi iyìn fu JEHOFA.

Digitized by Google

OWURỌ IJǪ. 21.

Psalmu 105.

EFI ǫpẹ́ fu Jehofa; ẹ pè orukǫ rẹ̀ : ẹ fi iṣẹ́ rẹ̀ hàn ninu awǫn enia.

2 Ẹ kǫnrin si i, ẹ kǫn orin mimǫ́ si i : ẹ ma sǫ̀rǫ iṣẹ́ iyanu rẹ̀ gbogbo.

3 Ẹ ma ṣogo li orukǫ rẹ̀ mimǫ́ : jẹ ki àiya awǫn ti nwá Jehofa ki o yọ̀.

4 Ẹ ma wá Jehofa, ati ipá rẹ̀ : ma wá oju rẹ̀ si i lailai.

5 Ẹ ma ranti iṣẹ́ iyanu rẹ̀ ti o ti ṣe; iṣẹ́ iyanu rẹ̀, ati idajǫ́ ẹnu rẹ̀;

6 Ẹnyin irú-ǫmmǫ Abrahamu iranṣẹ rẹ̀, ẹnyin awǫn ǫmmǫ Jakobu ayanfẹ rẹ̀.

7 On ni Jehofa Ọlọrun wa : idajǫ́ rẹ̀ mbẹ ni gbogbo aiye.

8 O ti ranti majẹmu rẹ̀ lailai, ọ̀rọ ti o ti pa li aṣẹ fu ẹgbẹrun iran.

9 Majẹmu ti o ba Abrahamu da, ati ibura rẹ̀ fu Isaaki;

10 O sì tẹnumǫ́ eyi na li ofin fu Jakobu, ati fu Israeli ni majẹmu aiye-raiye :

11 O nwipe, Iwǫ li emi o fi ilẹ Kanaan fu, ipín ilẹ-ini nyin.

12 Nigbati o ṣe pe kiun ni nwǫn wà ni iye; nitõtǫ, diẹ kiun, nwǫn sì ṣe alejò ninu rẹ̀.

13 Nigbati nwǫn nlǫ lati orilẹ ède kan de omiran, lati ilẹ ǫbba kan de ǫdǫ awǫn enia omiran;

14 On kò jẹ ki ẹnikẹni ki o ṣe wǫn ni iwǫsi, nitõtǫ, o ba awǫn ǫbba wi nitori wǫn;

15 Wipe, Ẹ má ṣe fi ǫwǫ́ kàn ẹni atorórosi mi, ki ẹ má sì ṣe awǫn woli mi ni ibi.

Digitized by Google

16 Pẹlu-pẹlu o pè lyan wá si ilẹ na : o ṣẹ́ gbogbo ọpá onjẹ.
17 O rán ọkọnri kan lọ siwaju wọn, eyini ni Josefu, ti a tà li ẹrú :
18 Ẹniti nwọn fi ṣẹ̀kẹ-ṣẹ̀kẹ pa lara ẹsẹ : a dè e ninu irin :
19 Titi igba ti ọ̀rọ rẹ̀ dé : ọ̀rọ JEHOFA dan a wò.
20 Ọbba ranṣẹ nwọn tú u silẹ; ani ijoye awọn enia, o sì jọwọ rẹ̀ lọ li omnira.
21 O fi i jẹ OLUWA ile rẹ̀, ati olori gbogbo ini rẹ̀ :
22 Lati ma ṣe akoso awọn ọmmọ-alade rẹ̀ nipa ifẹ́ rẹ̀; ati lati ma kọ́ awọn ìgbimọ rẹ̀ li ọgbọ́n.
23 Israeli sì wá si Egipti pẹlu ; Jakobu sì ṣe atipo ni ilẹ Hamu.
24 O sì mu awọn enia rẹ̀ bisi i pipọ̀-pipọ ; o sì mu wọn lagbara jù awọn ọtá wọn lọ.
25 O yi wọn li àiya pada lati korira awọn enia rẹ̀, lati ṣe arekereke si awọn iranṣẹ rẹ̀.
26 O rán Mose iranṣẹ rẹ̀ ; ati Aaron ẹniti o ti yàn.
27 Nwọn fi ọ̀rọ àmi rẹ̀ hàn ninu wọn, ati iṣẹ́ iyanu ni ilẹ Hamu.
28 O rán ọkunkun, o sì mu u ṣú; nwọn kò sì kọ ọ̀rọ rẹ̀.
29 O sọ omi wọn di ẹ̀jẹ, o sì pa ẹja wọn.
30 Ilẹ wọn bí ọpọlọ́ jade wá li ọpọlọpọ, ni iyẹwu awọn ọbba wọn.
31 O sọ̀rọ, onirũru eṣinṣin sì de, ati iná aṣọ ni gbogbo àgbegbe wọn.
32 O fi yinyín fu wọn li òjo, ati ọwọ́ iná ni ilẹ wọn.
33 O lù ajara wọn pẹlu, ati igi ọpọtọ wọn; o sì da igi àgbegbe wọn.

Digitized by Google

34 O sòrọ, eṣú sì de, ati kokoro, ati eyini li alniye,
35 Nwọn sì jẹ gbogbo ewebẹ ilẹ wọn, nwọn sì jẹ eso ilẹ wọn run.
36 O kọlù gbogbo akọbi pẹlu ni ilẹ wọn, gbogbo ãyo ipá wọn.
37 O mu wọn jade pẹlu, ti awọn ti fadaka ati wura : kò sì si alailera enia kan ninu awọn ẹya wọn.
38 Inu Egipti dùn nigbati nwọn lọ : nitori ti ẹru wọn bà wọn.
39 O nà awọ-sanma kan fu ibori wọn; ati iná lati fu wọn ni imọlẹ li oru.
40 Awọn enia na bère, o sì mu ẹiyẹ aparò wá, o sì fi onjẹ ọrun tẹ wọn lọrùn.
41 O là apatta, omi sì tú jade; nwọn nṣàn nibi gbigbẹ bi odò nla.
42 Nitori ti o ranti ileri rẹ mimọ́, ati Abrahamu iranṣẹ rẹ.
43 O sì fi ayọ̀ mu awọn enia rẹ jade, ati awọn ayanfẹ rẹ pẹlu inu didùn :
44 O sì fi ilẹ ti awọn keferi fu wọn : nwọn sì jogún iṣẹ́ ti awọn enia na;
45 Ki nwọn ki o le ma kiye si aṣẹ rẹ, ki nwọn ki o sì ma pa ofin rẹ mọ́. Ẹ ma fi iyìn fu JEHOFA.

ALẸ IJỌ. 21.

PSALMU 106.

EFI iyìn fu JEHOFA. Ẹ fi ọpẹ́ fu JEHOFA; nitori ti o ṣeun : nitori ti ãnu rẹ duro lailai.
2 Tali o le sòrọ iṣẹ́ agbara JEHOFA? tali o le fi gbogbo iyìn rẹ hàn?
3 Ibukún ni fu awọn ti nṣe idajọ́, ati ẹniti nṣe ododo nigba-gbogbo.

Digitized by Google

4 JEHOFA, fi oju-rere rẹ ti iwọ ni si awọn enia rẹ ṣe iranti mi : fi igbala rẹ bẹ mi wò ;
5 Ki emi ki o le ri ore ayanfẹ rẹ, ki emi ki o le yọ ni inu didùn orilẹ ède rẹ, ki emi ki o le ma ṣogo pẹlu awọn enia ilẹ rẹ.
6 Awa ti ṣẹ pẹlu awọn babba wa, awa ti dẹṣẹ, awa ti ṣe buburu.
7 Iṣẹ iyanu rẹ kò yé awọn babba wa ni Egipti; nwọn kò ranti ọpọlọpọ ãnu rẹ; ṣugbọn nwọn mu ọ binu nibi okun, ani nibi Okun pupa.
8 Ṣugbọn o gbà wọn là nitori orukọ rẹ, ki o le mu iṣẹ agbara rẹ nla di mimọ.
9 O ba Okun pupa wi pẹlu, o sì gbẹ : bẹ̃li o sìn wọn là ibú já bi ẹnipe larin aginjù.
10 O sì gbà wọn là li ọwọ́ ẹniti o korira wọn, o sì rà wọn li ọwọ́ ọtá ni.
11 Omi sì bò awọn ọtá wọn : ẹnikan wọn kò sì kù.
12 Nigbana ni nwọn gbà ọrọ rẹ gbọ́ ; nwọn sì kọnrin iyìn rẹ.
13 Nwọn kò sì pẹ gbagbé iṣẹ́ rẹ ; nwọn kò duro dè ìmọ rẹ :
14 Ṣugbọn nwọn fẹ ifẹkufẹ gidigidi li aginjù, nwọn sì dan Ọlọrun wò ninu aṣálẹ.
15 O sì fi ifẹ́ wọn fu wọn; o sì fi rirù si ọkkàn wọn.
16 Nwọn ṣe ilara Mose pẹlu ni ibudo, ati Aaron ẹni mimọ́ JEHOFA.
17 Ilẹ là o sì gbé Datan mì, o sì bò ẹgbẹ Abiramu mọlẹ.
18 Iná kan sì ràn ninu ẹgbẹ wọn; ọwọ́ iná na jó awọn enia buburu.
19 Nwọn ṣe ẹgbọrọ malu ni Horebu, nwọn sì foribalẹ fu ere didà.
20 Bayi ni nwọn pa ogo wọn dà si aworan malu ti njẹ koriko.

Digitized by Google

21 Nwọn gbagbé Ọlọrun olugbala wọn, ti o
ti ṣe ohun nla ni Egipti;
22 Iṣẹ iyanu ni ilẹ Hamu, ati ohun ẹ̀ru lẹba
Okun pupa.
23 Nitorina li o ṣe wipe on o run wọn,
ki o má ṣe pe Mose ayanfẹ rẹ̀ duro niwaju
rẹ̀ nibi ẹya-na, lati yi ibinu rẹ̀ pada, ki o má
ba run wọn.
24 Nitõtọ, nwọn kò kà ilẹ didara ni si,
nwọn kò gbà ọ̀rọ rẹ̀ gbọ́ :
25 Ṣugbọn nwọn okùn ninu agọ́ wọn, nwọn
kò sì fetisi ohùn JEHOFA.
26 Nitorina li o ṣe gbé ọwọ́ rẹ̀ soke si
wọn, lati bì wọn ṣubu li aginjù :
27 Lati bì irú-ọmọ wọn ṣubu pẹlu ninu
awọn orilẹ ède, ati lati fọ́n wọn ká kiri ni
ilẹ na.
28 Nwọn da ara wọn pọ̀ pẹlu mọ́ Baali-
peoru, nwọn sì njẹ ẹbọ ti awọn okú.
29 Bayi ni nwọn fi ihumọ wọn mu u binu :
arun na sì fọ́ si arin wọn.
30 Nigbana ni Fineha dide duro, o sì ṣe
idajọ́ : bẹ̃li arun ma sì da.
31 A sì kà eyi na si i fu li ododo de iran
gbogbo si i lailai.
32 Nwọn bi i ninu pẹlu nibi omi ìja, bẹ̃li
o buru fu Mose nitori wọn :
33 Nitori ti nwọn mu ọkkàn rẹ̀ binu, bẹ̃li
o fi ẹnu rẹ̀ sọ ọ̀rọ̀ alyẹ.
34 Nwọn kò run awọn orilẹ ède na, niti
ẹniti JEHOFA paṣẹ fu wọn :
35 Ṣugbọn nwọn dàpọ mọ́ awọn keferi,
nwọn sì kọ́ iṣẹ wọn.
36 Nwọn sì sìn awọn orisa wọn : ti o di
idanwò fu wọn.
37 Nitõtọ nwọn fi ọmmọkọnri wọn ati
ọmmọbiri wọn rubọ si èṣu,

Digitized by Google

38 Nwọn sì ta ẹ̀jẹ, alaìṣẹ silẹ, ani ẹ̀jẹ ti awọn ọmmọkọnri wọn ati ti awọn ọmmọbiri wọn, ti nwọn fi rubọ si awọn orisa Kanaan : ilẹ na sì di almọ́ fu ẹ̀jẹ.

39 Bayi ni nwọn fi iṣẹ́ ara wọn di alaìmọ́, nwọn sì ṣe panṣaga lọ pẹlu ihumọ wọn.

40 Nitorina ni ibinu JEHOFA ṣe ràn si awọn enia rẹ̀, tobẹ̃ ti o fi korira awọn enia ilẹ rẹ̀.

41 O sì fi wọn le awọn keferi lọwọ́ ; awọn ti korira wọn sì ṣe olori wọn.

42 Awọn ọtá wọn pẹlu ni wọn lara, nwọn sì mu wọn sìn labbẹ ọwọ́ wọn.

43 Igba pupọ̀ li o gbà wọn ; ṣugbọn nwọn fi ìmọ wọn mu u binu, a sì rẹ̀ wọn silẹ nitori ẹ̀ṣẹ wọn.

44 Ṣugbọn o juba ipọnju wọn, nigbati o gbọ́ ẹkún wọn.

45 O sì ranti majẹmu rẹ̀ fu wọn, o sì ronupiwada gẹgẹ bi ọpọlọpọ ãnu rẹ̀.

46 O sì mu wọn di ẹni ãnu fu lọdọ gbogbo awọn ti o kó wọn ni igbekun.

47 JEHOFA, Ọlọrun wa, gbà wa là, ki o sì ṣà wa jọ kuro ninu awọn keferi, lati ma fi ọpẹ́ fu orukọ mimọ́ rẹ, ati lati ma ṣogo ninu iyìn rẹ.

48 Olubukun ni JEHOFA, Ọlọrun Israeli, lati aiye-raiye : ki gbogbo awọn enia ki o sì ma wipe, Amin. Ẹ fi iyìn fu JEHOFA.

OWURỌ IJỌ. 22.

PSALMU 107.

EFI ọpẹ́ fu JEHOFA, nitori ti o ṣeun : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.

Digitized by Google

2 Jẹ ki awọn oludande ti JEHOFA ki o wi bẹ̃, ẹniti o rà-pada kuro li ọwọ́ ọtá ni;
3 O sì kó wọn jọ lati ilẹ wọn-ni wá, lati ìla-õrùn wá, ati lati ìwọ-õrùn, lati ariwa, ati lati gusù wá.
4 Nwọn nrìn ká kiri li aginjù ni ibi rére; nwọn kò ri ilu-nla lati ma gbé.
5 Ebi pipa ati ongbẹ, o rẹ̀ ọkkàn wọn ninu wọn.
6 Nigbana ni nwọn kigbe pè JEHOFA ninu ipọnju wọn, o sì yọ wọn kuro ninu iṣẹ́ wọn.
7 O sì mu wọn jade nipa ọna títọ, ki nwọn ki o le lọ si itẹdo ilu-nla.
8 Enia iba ma yìn JEHOFA nitori ore rẹ̀, ati nitori iṣẹ́ iyanu rẹ̀ si awọn ọmmọ enia!
9 Nitori ti o tẹ́ ifẹ́ ọkkàn lọrùn, o sì fi ore kún ọkkàn ti ebi npa.
10 Irú awọn ti o joko li òkunkun ati li ojiji ikú, ti a dè ninu ipọnju ati ni irin;
11 Nitori ti nwọn ṣọ̀tẹ si ọ̀rọ Ọlọrun, nwọn sì gàn ìmọ Ọgá-ogo:
12 Nitorina o fi lãlã rẹ̀ àiya wọn silẹ; nwọn ṣubu, kò sì si oluranlọwọ.
13 Nigbana ni nwọn kigbe pè JEHOFA ninu iṣẹ́ wọn, o sì gbà wọn là ninu ipọnju wọn.
14 O mu wọn jade kuro ninu òkunkun ati ojiji ikú, o sì da ìde wọn meji.
15 Enia iba ma yìn JEHOFA nitori ore rẹ̀, ati nitori iṣẹ́ iyanu rẹ̀ si awọn ọmmọ enia!
16 Nitori ti o fọ́ awọn ilẹkun idẹ, o sì ke awọn ọpá irin li agbede-meji.
17 Aṣiwere nitori irekọja wọn, ati nitori èṣẹ wọn, oju npọ́n wọn.
18 Ọkkàn wọn kọ̀ onjẹ-konjẹ; nwọn sì sumọ́ etí ẹnu ọna ikú.
19 Nigbana ni nwọn kigbe pè JEHOFA, ninu iṣẹ́ wọn, o sì gbà wọn là ninu ipọnju wọn.

Digitized by Google

20 O rán ỳrỵ rẹ̀, o sì mu wọn lara da, o sì gbà wọn kuro ninu iparun wọn.
21 Enia iba ma yìn Jehofa nitori ore rẹ̀, ati nitori iṣẹ́ iyanu rẹ̀ si awọn ọmmọ enia!
22 Sì jẹ ki nwọn ki o ru ẹbọ ọpẹ́, ki nwọn ki o sì fi ayọ̀ sọ̀rọ iṣẹ́ rẹ̀.
23 Awọn ti nsọkalẹ lọ si okun ninu ọkọ̀, ti nwọn nṣiṣẹ ninu omi nla;
24 Awọn nwọnyi ri iṣẹ́ Jehofa, ati iṣẹ́ iyanu rẹ̀ ninu ibú.
25 Nitori ti o paṣẹ, o sì mu ẹfufu dide, ti o gbé riru omi rẹ̀ soke.
26 Nwọn gòke lọ si ọrun, nwọn sì tún sọkalẹ lọ si ibú; ọkkàn wọn di omi nitori ipọnju.
27 Nwọn nta gbọngbọn sihin sọhun, nwọn nta gbọngbọn bi ọmọti enia, ìmọ wọn sì de opin.
28 Nigbana ni nwọn kigbe pè Jehofa ninu ipọnju wọn, o sì yọ wọn kuro ninu iṣẹ́ wọn.
29 O sọ ẹfufu di idakẹ-ọrọ, bẹ̃ni riru omi rẹ̀ duro jẹ.
30 Nigbana ni nwọn yọ̀, nitori ti ara wọn balẹ; bẹ̃li o mu wọn wa si ibi ebute ifẹ́ wọn.
31 Enia iba ma yìn Jehofa nitori ore rẹ̀, ati nitori iṣẹ́ iyanu rẹ̀ si awọn ọmmọ enia!
32 Ki nwọn ki o gbé e ga pẹlu ni ijọ awọn enia, ki nwọn ki o sì yìn i ninu ijọ awọn àgba.
33 O sọ awọn odò di aginjù, ati awọn ìsan-omi di ilẹ gbigbẹ;
34 Ilẹ èlẹtu loju di aṣalẹ, nitori ìwa-buburu awọn ti o wà ninu rẹ̀.
35 O sọ aginjù di adagun omi, ati ilẹ gbigbẹ di isun omi.
36 Nibẹ̀ li o sì mu ẹniti ebi npa joko, ki nwọn ki o le mura itẹdo ilu-nla;
37 Ki nwọn ki o sì ma fọn irugbin ilẹ na, ki

Digitized by Google

nwọn ki o sì ma gbìn agbala ajara wọn, ti yio ma so òpọ eso fu wọn.

38 O bùsi i fu wọn pẹlu, bẹ̀ni nwọn sì pọ̀ si i gidigidi; kò sì jẹ ki ohun òsin wọn ki o fà sẹhin.

39 Ẹ̀wẹ, nwọn bukun, nwọn si fà sẹhin, nipa inira, ipọnju, ati ikãnu.

40 O dà èṣan lù awọn ọmmọ-alade, o sì mu wọn rìn kiri ni ijù, nibiti òna kò si.

41 Ṣugbọn o gbé talakà leke kuro ninu ipọnju, o sì sọ ọ di olori ile bi agbo ẹran.

42 Awọn olododo yio ri i, nwọn o sì yọ̀: gbogbo èṣẹ ni yio sì pa ẹnu rẹ̀ mọ́.

43 Ẹnikẹni ti o gbọ́n, ti yio sì ma kiye si nkan nwọnyi, awọn na li oyé iṣeun-ifẹ́ JEHOFA yio ma yé.

ALẸ IJỌ. 22.

PSALMU 108.

OLỌRUN, ọkkàn mi ti mura, emi o ma fi ogo mi kọrin, emi o ma fi bù iyìn.

2 Jí, èlo orin mimọ́ ati dùru: emi tikara mi yio sì jí ni kutukutu.

3 Emi o ma yìn ọ, JEHOFA, ninu awọn enia: emi o sì ma kọrin si ọ ninu awọn orilẹ ède.

4 Nitori ti ãnu rẹ̀ tobi jù ọrun lọ: ati otitọ rẹ̀ de awọn awọ-sanma.

5 Gbigbe-ga ni iwọ Olọrun, jù awọn ọrun lọ: ati ogo rẹ̀ jù gbogbo ilẹ̀ aiye lọ;

6 Ki a le gbà olufẹ rẹ̀ là: fi ọwọ́ ọtún rẹ̀ ṣe igbala, ki o sì da mi lohùn.

7 Olọrun ti sòrọ ninu ìwa-mimọ́ rẹ̀; Emi o yọ̀, emi o pín Ṣekemu, emi o sì wọn afonifoji Sukotu.

8 Ti emi ni Gileadi; ti emi ni Manase;

Digitized by Google

Efraimu pẹlu li agbara ori mi; Juda li olofin mi;

9 Moabu li afòkoko mi; lori Edomu li emi o bó bàta mi si; lori Filistia li emi o ṣogo.

10 Tani yio mu mi wá sinu ilu-nla alagbara ni? tani yio sìn mi lọ si Edomu?

11 Iwọ Ọlọrun kó, ẹniti o ti ṣa wa tì? Ọlọrun, iwọ kì yio sì ba awọn ogun wa jade lọ?

12 Fu wa ni iranlọwọ ninu ipọnju : nitori asan ni iranlọwọ enia.

13 Nipa ti Ọlọrun li awa o ṣe iṣe agbara : nitori on ni yio tẹ awọn ọtá wa mọlẹ.

PSALMU 109.

MÁ ṢE pa ẹnu rẹ mó, Ọlọrun iyìn mi;

2 Nitori ti ẹnu awọn enia buburu, ati ẹnu awọn ẹlẹtan yà silẹ si mi : nwọn ti nfi ahọn eke sọrọ si mi.

3 Nwọn sì fi ọrọ irira yi mi ká kiri; nwọn sì mba mi jà li alàinidi.

4 Nipò ifẹ mi nwọn nṣe awọn ọtá mi : ṣugbọn mo fi ara mi fu adura.

5 Nwọn sì fi ibi san ire fu mi, ati irira fu ifẹ mi.

6 Yàn enia buburu tì i : jẹ ki Satan ki o duro li ọwó ọtún rẹ.

7 Nigbati a o ṣe idajó rẹ, ki a da a lẹbi : ki adura rẹ ki o di èṣẹ.

8 Ki awọn ọjọ rẹ ki o kuru; ki ẹlomiran ki o rọpò iṣẹ rẹ.

9 Ki awọn ọmmọ rẹ ki o di alàinì-babba, ki aya rẹ ki o di opó.

10 Jẹ ki awọn ọmmọ rẹ ki o di alarinkiri,

Digitized by Google

ki nwọn ki o ma ṣagbe : ki nwọn ki o ma wá onjẹ kiri ni ibi ofo.

11 Jẹ ki alọnilọwọ-gbà ki o mu ohun gbogbo ti o ni ; ki awọn alejò ki o bà iṣẹ rẹ jẹ.

12 Ki ẹnikẹni ki o má si lati ṣãnu fu u : bẹ̃ni ki o má ṣe jẹ ki ẹnikan ki o sì lati ṣe oju-rere si awọn ọmmọ rẹ alaìni-babba.

13 Ki a ke iran rẹ kuro; ati ni iran ti mbò ki orukọ wọn ki o parẹ.

14 Ki a ma ranti ẹ̀ṣẹ̀ awọn babba wọn lọdọ JEHOFA; má sì jẹ ki a nù ẹ̀ṣẹ̀ iya rẹ nù.

15 Jẹ ki nwọn ki o wà niwaju JEHOFA nigba-gbogbo, ki o le ke iranti wọn kuro lori ilẹ.

16 Nitori ti kò ranti lati ṣãnu, ṣugbọn o ṣe inunibini si ọkọnri talakà ati alaìni ni, ki o le pa onirobinujẹ ọkkàn.

17 Bi o ti fẹ egún, bẹ̃ni ki o de si i : bi inu rẹ kò ti dùn si ire, bẹ̃ni ki o jìna si i.

18 Bi o ti fi egún wọ̀ ara rẹ li aṣọ bi ẹ̀wu, bẹ̃ni ki o wá sinu ifọn rẹ bi omi, ati bi oróro sinu egungun rẹ.

19 Jẹ ki o ri fu u bi ẹ̀wu ti o bò o lara, ati fu amure ti o fi gbajá nigba-gbogbo.

20 Jẹ ki eyi ki o jẹ ère ti awọn ọtá mi lati ọwọ́ JEHOFA wá, ati ti awọn ti nsọ̀rọ ibi si ọkkàn mi.

21 Ṣugbọn iwọ ṣe fu mi, JEHOFA OLUWA, nitori orukọ rẹ : nitori ti ãnu rẹ dara, iwọ gbà mi là.

22 Nitori pe talakà ati alaìni li emi, àiya mi sì gbọgbẹ ninu mi.

23 Emi lọ tan bi ojiji ti o nfà sẹhin, emi ntì soke tì sodò bi eṣú.

24 Ẽkun mi hù nipa igbawẹ ; eran ara mi gbẹ nitori aìnisanra.

Digitized by Google

25 Emi di ẹ̀gan si wọn pẹlu : nigbati nwọn ba wò mi, nwọn gbọ̀n ori wọn.
26 Ràn mi lọwọ́, JEHOFA, Olọrun mi : gbà mi là gẹgẹ bi ãnu rẹ.
27 Ki nwọn ki o le mọ̀ pe ọwọ́ rẹ li eyi ; pe iwọ JEHOFA li o ṣe e.
28 Jẹ ki nwọn ki o ma gegún, ṣugbọn iwọ ma sùre : nigbati nwọn ba dide, ki oju ki o tì wọn; ṣugbọn jẹ ki iranṣẹ rẹ ki o yọ̀.
29 Jẹ ki a fi ìtiju wọ̀ awọn ọ̀tá mi li aṣọ, ki nwọn ki o sì fi idaru-dàpọ bò ara wọn, bi ẹnipe ẹ̀wu.
30 Emi o ma fi ẹnu mi yìn JEHOFA gidigidi; nitõtọ, emi o ma yìn i ninu ọ̀pọ awọn enia.
31 Nitori ti yio duro li ọwọ́ ọ̀tún talakà, lati gbà a là lọwọ́ awọn ti o nda ọkàn rẹ̀ lẹbi.

OWURỌ IJỌ. 23.

PSALMU 110.

JEHOFA wi fu OLUWA mi pe, Iwọ joko li ọwọ́ ọ̀tún mi, titi emi o fi sọ awọn ọ̀tá rẹ di apoti itisẹ rẹ.
2 JEHOFA yio rán ọpá agbara rẹ lati Sion jade wa : iwọ jẹ olori larin awọn ọ̀tá rẹ.
3 Awọn enia rẹ yio fẹ li ọjọ́ agbara rẹ, ninu ẹwà ìwa-mimọ́ jù ati inu owurọ̀ wá : iwọ ni ìri ewe rẹ.
4 JEHOFA ti bura, kì yio sì ronupiwada pe, Iwọ li alufa kan titi lai nipa ẹsẹ ti Melkisedeki.
5 OLUWA li ọwọ́ ọ̀tún rẹ ni yio lù awọn ọbba jalẹ li ọjọ́ ibinu rẹ̀.
6 Yio ṣe idajọ́ ninu awọn keferi, yio fi okú kún ibi wọn-ni; yio fọ́ awọn ori lori ilẹ pupọ̀.

Digitized by Google

7 Yio ma mu ninu odò na li ọna : nitorina ni yio ṣe gbé ori soke.

Psalmu 111.

EMA yìn Jehofa. Emi o ma yìn Jehofa tinu-tinu mi, ninu ijọ awọn ẹni diduro ṣinṣin, ati ni ijọ awọn enia.

2 Iṣẹ́ Jehofa tobi, iwá kiri ni lọwọ́ gbogbo awọn ti o ni ifẹ rẹ̀ ninu.

3 Iṣẹ́ rẹ̀ li ọlá on ogo, ododo rẹ̀ si duro lailai.

4 O mu iṣẹ́ iyanu rẹ̀ ṣe iranti : olore ọfẹ ni Jehofa o sì kún fu ãnu.

5 O ti fi onjẹ fu awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀ : yio ma ṣe iranti majẹmu rẹ̀ lai.

6 O ti fi iṣẹ́ agbara rẹ̀ hàn awọn enia rẹ̀, ki o le fu wọn ni ilẹ-ini ti awọn keferi.

7 Otitọ ati idajọ́ ni iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀; gbogbo ofin rẹ̀ li o daniloju.

8 Nwọn duro lailai ati lailai, ninu otitọ ati iduro ṣinṣin li a ṣe wọn.

9 O rán idande si awọn enia rẹ̀ : o ti paṣẹ majẹmu rẹ̀ lailai : mimọ́ ati ọ̀wọ̀ li orukọ rẹ̀.

10 Ìbẹ̀ru Jehofa ni ipilẹṣẹ ọgbọ́n : oyé ọna rere ni gbogbo nwọn ni ti npa ofin rẹ̀ mọ́ : iyìn rẹ̀ duro lailai.

Psalmu 112.

EMA yìn Jehofa. Ibukún ni fu ẹniti o bẹ̀ru Jehofa, ti inu rẹ̀ dùn jọjọ li ofin rẹ̀.

2 Irú-ọmmọ rẹ̀ yio lagbara ni ilẹ aiye : iran ẹni diduro ṣinṣin li a o bukún fu.

3 Ọlà ati ọrọ̀ yio wà ni ile rẹ̀ : ododo rẹ̀ sì duro lailai.

Digitized by Google

4 Fu ẹni diduro ṣinṣin ni imọlẹ mọ́ li òkunkun : olore ọfẹ o sì kún fu ãnu, o sì ṣe olododo.

5 Enia rere fi oju-rere hàn, a sì win-ni : imoye ni yio ma fi là ọ̀na iṣẹ́ rẹ̀.

6 Nitõtọ a kì yio yi i nipò pada lailai : olododo yio wà ni iranti titi aiye.

7 Kì yio bẹ̀ru ihin buburu : àiya rẹ̀ ti mu ọ̀na kan, o ngbẹkẹle ,JEHOFA.

8 Àiya rẹ̀ ti mulẹ, kì yio bẹ̀ru, titi yio fi ri ifẹ́ rẹ̀ lori awọn ọtá rẹ̀.

9 O ti fọn kalẹ, o ti fi fu talakà ; ododo rẹ̀ duro lailai ; ọlá li a o fi gbé iwo rẹ̀ ga.

10 Awọn enia buburu yio ri i, inu wọn yio bajẹ ; yio pa ehin rẹ̀ keke, yio sì di omi : ifẹ́ awọn enia buburu yio ṣegbé.

PSALMU 113.

EMA yìn JEHOFA. Ẹ ma yìn, iranṣẹ JEHOFA, ẹ ma yìn orukọ JEHOFA.

2 Ibukún li orukọ JEHOFA lati isisiyi lọ ati siwaju lailai.

3 Lati ìla-õrùn titi o fi de ìwọ rẹ̀ orukọ JEHOFA ni ki a yìn.

4 JEHOFA ga jù gbogbo awọn orilẹ ède lọ, ogo rẹ̀ sì jù awọn ọrun lọ.

5 Tali o dabi JEHOFA, Ọlọrun wa, ti o ngbé oke giga,

6 Ẹniti o rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ lati bẹ̀ ohun ti o wà li ọrun ati li aiye wò !

7 O gbé talakà soke lati inu erupẹ̀ wá, o sì gbé alalni soke lati ori àtan wá ;

8 Ki o le gbé e kalẹ pẹlu awọn ọmmọ-alade, ani pẹlu awọn ọmmọ-alade ti awọn enia rẹ̀.

Digitized by Google

9 O mu àgan obiri gbé inu ile, ki o le ma ṣe oninu-didùn iya awọn ọmmọ. Ẹ ma yìn JEHOFA.

ALẸ IJỌ. 23.

PSALMU 114.

NIGBATI Israeli jade ni Egipti, ti ara ile Jakobu kuro ninu àjeji èdè enia;
2 Juda ni ibi mímọ́ rẹ̀, Israeli ni ijọba rẹ̀.
3 Okun ri i, o sì sá: a lé Jordan pada sẹhin.
4 Awọn òke nla nfò bi àgbo, ati awọn òke kekere bi awọn ọdọ agutan.
5 Kili o ṣe ọ, iwọ okun, ti iwọ fi sá? iwọ Jordan, ti a fi lé ọ sẹhin.
6 Ẹnyin òke nla, ti ẹ fi nfò bi àgbo; ati ẹnyin òke kekere bi ọdọ agutan?
7 Wa-rìri, iwọ ilẹ aiye, niwaju OLUWA, niwaju Ọlọrun Jakobu;
8 Ẹniti o sọ apatta di adagun omi, ati okuta ibọn di orisun omi.

PSALMU 115.

KÌ iṣe fu wa, JEHOFA, kì iṣe fu wa, bikoṣe orukọ rẹ li a fi ogo fu, nitori ãnu rẹ, ati nitori otitọ rẹ.
2 Nitori kili awọn keferi yio ṣe wipe, Nibo li Ọlọrun wọn wà nisisiyi?
3 Ṣugbọn Ọlọrun wa mbẹ ninu awọn ọrun: o ti nṣe ohun ti o wù u.
4 Fadaka ati wura li ere wọn, iṣẹ́ ọwọ́ enia.
5 Nwọn li ẹnu, ṣugbọn nwọn kò sọ̀rọ: nwọn li oju, ṣugbọn nwọn kò ri iran.
6 Nwọn li etí, ṣugbọn nwọn kò gbọran: nwọn ni imọ, ṣugbọn nwọn ko gbõrun.

Digitized by Google

7 Nwọn li ọwọ́, ṣugbọn nwọn kò lò o : nwọn li ẹsẹ, ṣugbọn nwọn kò rìn : bẹ̃ni nwọn kò sọ̀rọ lati ọfọn wọn jade.
8 Awọn ti nṣe wọn dabi wọn; bẹ̃li olukuluku ẹniti o gbẹ̀kẹ̀le wọn.
9 Israeli, iwọ gbẹ̀kẹ̀le JEHOFA : on ni iranlọwọ wọn ati asà wọn.
10 Ara ile Aaron gbẹ̀kẹ̀le JEHOFA : on ni iranlọwọ wọn ati asà wọn.
11 Ẹnyin ti o bẹ̀ru JEHOFA, gbẹ̀kẹ̀le JEHOFA : on ni iranlọwọ wọn ati asà wọn.
12 JEHOFA ti nṣe iranti wa : yio busi i fu wa; yio busi i fu ara ile Israeli; yio busi i fu ara ile Aaron.
13 Yio busi i fu awọn ti o bẹ̀ru JEHOFA, ati ewe ati àgba.
14 JEHOFA yio mu nyin bisi i siwaju ati siwaju, ẹnyin ati awọn ọmmọ nyin.
15 Ẹnyin li ẹni ibukún ti JEHOFA, ti o da ọrun on aiye.
16 Ọrun, ani awọn ọrun ni ti JEHOFA; ṣugbọn ilẹ aiye li o fi fu awọn ọmmọ enia.
17 Awọn okú kò yìn JEHOFA, tabi awọn ti o sọkalẹ lọ sinu idakẹ.
18 Ṣugbọn awa o ma fi ibukún fu JEHOFA, lati igba yi lọ ati siwaju lailai. Ẹ yìn JEHOFA.

OWURỌ IJỌ. 24.

PSALMU 116.

MO fẹ JEHOFA, nitori ti o gbọ́ ohùn mi ati ẹbẹ mi.
2 Nitori ti o dẹ etí rẹ̀ si mi, nitorina li emi o ṣe ma kepè e niwọn ọjọ mi.

Digitized by Google

3 Ikãnu ikú yi mi ká, ati irora isà okú dì mi mu; mo ri iyǫnu ati ikãnu.
4 Nigbana ni mo pè orukǫ JEHOFA; JEHOFA, emi bẹ ǫ, gbà ǫkkàn mi.
5 Olore ǫfẹ ni JEHOFA, ati olododo; nitõtǫ, alãnu li Ǫlǫrun wa.
6 JEHOFA pa awǫn òpe mǫ́: a rẹ mi silẹ tan, o sì ràn mi lǫwǫ́.
7 Pada si ibi isimi rẹ, iwǫ ǫkkàn mi; nitori ti JEHOFA ṣe ɔ̀pǫlǫpǫ fu ǫ.
8 Nitori ti iwǫ gbà ǫkkàn mi lǫwǫ́ ikú, oju mi lǫwǫ́ omije, ati ẹsẹ mi lǫwǫ́ iṣubu.
9 Emi o ma rìn niwaju JEHOFA ni ilẹ ti awǫn alãye.
10 Emi gbagbǫ́, nitorina li emi ṣe sǫ: mo ri ipǫnju gidigidi.
11 Mo wi ni iyara mi pe, Eke ni gbogbo awǫn enia.
12 Kili emi o fi fu JEHOFA nitori gbogbo ore rẹ si mi?
13 Emi o mu ago igbala, emi o sì ma kepè orukǫ JEHOFA.
14 Emi o san ileri ifẹ mi fu JEHOFA nisisiyi li oju awǫn enia rẹ gbogbo.
15 Iyebiye ni ikú awǫn enia mimǫ́ rẹ li oju JEHOFA.
16 JEHOFA, nitõtǫ iranṣẹ rẹ li emi; iranṣẹ rẹ li emi, ati ǫmmǫkǫnri ti iranṣẹ obiri rẹ: iwǫ ti tú ìde mi.
17 Emi o ru ẹbǫ ǫpẹ́ si ǫ, emi o ma pè orukǫ JEHOFA.
18 Emi o san ileri ifẹ mi fu JEHOFA nisisiyi niwaju gbogbo awǫn enia mimǫ́ rẹ,
19 Ninu agbala ti ile JEHOFA, li arin rẹ, iwǫ Jerusalemu. Ẹ yìn JEHOFA.

Digitized by Google

Psalmu 117.

EMA yìn Jehofa, ẹnyin orilẹ ède gbogbo : ẹ yìn i, ẹnyin gbogbo awọn enia.

2 Nitori ti iṣeun ãnu rẹ̀ pọ̀ si wa : ati otitọ Jehofa duro lailai. Ẹ yìn Jehofa.

Psalmu 118.

EFI ọpẹ́ fu Jehofa ; nitori ti o ṣeun : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.

2 Jẹ ki Israeli ki o wi nisisiyi pe, ãnu rẹ̀ duro lailai.

3 Jẹ ki ara ile Aaron ki o wi nisisiyi pe, ãnu rẹ̀ duro lailai.

4 Jẹ ki awọn ti o bèru Jehofa ki o wi nisisiyi pe, ãnu rẹ̀ duro lailai.

5 Mo kepè Jehofa ninu ipọnju : Jehofa da mi lohùn, o sì gbé mi kà ibi àye nla.

6 Jehofa mbẹ ni ìha ti emi ; emi kì yio bèru : kili awọn enia le ṣe si mi ?

7 Jehofa gbeja mi pẹlu awọn ti nràn mi lọwọ́ : nitorina li emi o ṣe ri ifẹ́ mi lori awọn ti o korira mi.

8 O ya lati gbẹ̀kẹ̀le Jehofa, jù ati gbẹ̀kẹ̀le awọn enia lọ.

9 O ya lati gbẹ̀kẹ̀le Jehofa, ju ati gbẹ̀kẹ̀le awọn ọmmọ-alade lọ.

10 Gbogbo awọn orilẹ ède yi mi ká kiri : ṣugbọn li orukọ Jehofa emi o pa wọn run.

11 Nwọn yi mi ká kiri ; nitõtọ, nwọn yi mi ká kiri : ṣugbọn li orukọ Jehofa emi o pa wọn run.

12 Nwọn yi mi ká kiri bi oyin ; a sì pa wọn bi iná ẹgún : li orukọ Jehofa emi o sá pa wọn run.

13 Iwọ tì mi gidigidi ki emi ki o le ṣubu : ṣugbọn Jehofa ràn mi lọwọ́.

14 Jehofa li agbara ati orin mi, o sì di igbala mi.

Digitized by Google

15 Ohùn ayǫ́ atì ti igbala mbẹ ninu agǫ́ ti awǫn olododo : ǫwǫ́ ǫtún JEHOFA nṣe iṣe agbara.
16 Ǫwǫ́ ǫtún JEHOFA li a gbéga : ǫwǫ́ ǫtún JEHOFA nṣe iṣe agbara.
17 Emi kì yio kú, bikoṣe yiyè, ki emi sì ma sǫ̀rǫ awǫn iṣẹ́ JEHOFA.
18 JEHOFA nà mi gidigidi : ṣugbǫn kò fi mi fu ikú.
19 Ṣí ilẹkun ẹnu ǫna ododo silẹ fu mi : emi o wǫ̀le tǫ̀ wǫn, emi o ma yìn JEHOFA :
20 Ẹnu ǫna JEHOFA na, ninu eyi ti awǫn olododo yio wǫ̀.
21 Emi o yìn ǫ : nitori ti iwǫ gbohùn mi, iwǫ sì di igbala mi.
22 Okuta ti awǫn imǫle kǫ̀ silẹ li o di pataki igun ile.
23 Eyi ni iṣe JEHOFA; o ṣe iyanu li oju wa.
24 Eyi li ǫjǫ ti JEHOFA da; awa o ma yǫ̀, inu wa yio sì ma dùn ninu rẹ̀.
25 Ṣe igbala nisisiyi, emi mbẹ̀ ǫ, JEHOFA; JEHOFA, emi mbẹ̀ ǫ, rán alafia.
26 Olubukún li ẹniti o wá li orukǫ JEHOFA : awa ti fi ibukún fu ǫ lati ile JEHOFA wá.
27 Ǫlǫrun ni JEHOFA, ti o ti fi imǫlẹ hàn wa : ẹ fi okùn dì ẹbǫ na mǫ́ iwo pepele na.
28 Iwǫ li Ǫlǫrun mi, emi o sì ma yìn ǫ : iwǫ li Ǫlǫrun mi, emi o ma gbé ǫ ga.
29 Ẹ fi ǫpẹ́ fu JEHOFA; nitori ti o ṣeun : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.

ALẸ IJǪ. 24.

PSALMU 119.

ALEFU.

IBUKÚN ni fu awǫn ẹniti o pé li ǫna na, ẹniti nrìn ninu ofin JEHOFA.

Digitized by Google

2 Ibukún ni fu awọn ti npa ẹrí rẹ mọ́, ẹniti sì nwá a kiri tinu-tinu gbogbo.
3 Nwọn kò dẹṣẹ pẹlu : nwọn nrìn li ọ̀na rẹ̀.
4 Iwọ ti paṣẹ fu wa lati pa ẹkọ́ rẹ mọ́ gidigidi.
5 Ọ̀na mi iba jẹ là silẹ lati ma pa ẹkọ́ rẹ mọ́!
6 Nigbana li oju kì yio tì mi, nigbati emi ba njuba ofin rẹ gbogbo.
7 Emi o ma fi àiya diduro ṣinṣin yìn ọ, nigbati emi ba ti kọ́ adajọ́ ododo rẹ.
8 Emi o pa aṣẹ rẹ mọ́ : má ṣe kọ̀ mi silẹ patapata.

Beti.

9 Nipa ewo li ọmmọkọnri yio fi mu ọ̀na rẹ̀ mọ́? nipa ikiye si i gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
10 Tinu-tinu mi gbogbo li emi fi ṣe afẹri rẹ : má ṣe jẹ ki emi ma rìn kiri kuro ninu ofin rẹ.
11 Ọ̀rọ rẹ ni mo pamọ́ li àiya mi, ki emi ki o má ba ṣẹ̀ si ọ.
12 Olubukún ni iwọ, Jehofa : kọ́ mi li aṣẹ rẹ.
13 Ẹnu mi li emi fi nsọ gbogbo idajọ́ ẹnu rẹ.
14 Emi ti nyọ̀ nipa ọ̀na ẹrí rẹ, to bi ẹnipe gbogbo ọrọ̀.
15 Emi o ṣe aṣaro ninu ẹkọ́ rẹ, emi o sì ma juba ọ̀na rẹ.
16 Emi o ma ṣe inu-didùn ninu aṣẹ rẹ : emi kì yio gbagbé ọ̀rọ rẹ.

Gimeli.

17 Fi ọ̀pọlọpọ ba iranṣẹ rẹ ṣe, ki emi ki o le wà lãye, ki emi ki o ma pa ọ̀rọ rẹ mọ́.

Digitized by Google

18 Iwọ là mi li oju, ki emi ki o le ma wò ohun iyanu wọn-ni lati inu ofin rẹ jade.
19 Alejò li emi ni ilẹ aiye : má ṣe pa ofin rẹ mọ́ fu mi.
20 Àiya mi bù nitori ifojusọna si idajọ́ rẹ nigba-gbogbo.
21 Iwọ ti ba awọn agberaga wi, ti a ti fi gegún ẹniti o ti ṣìna kuro nipa ofin rẹ.
22 Mu ẹ̀gan ati àbukun kuro lara mi ; nitori ti emi ti pa ẹ̀rí rẹ mọ́.
23 Awọn ọmmọ-alade joko pẹlu nwọn nsọ̀rọ si mi : ṣugbọn iranṣẹ rẹ nṣe aṣaro ninu aṣẹ rẹ :
24 Ẹ̀rí rẹ pẹlu ni didùn-inu mi ati ìgbimọ mi :

Daleti.

25 Ọkkàn mi lẹ̀ mọ́ erupẹ̀ : iwọ ṣọ mi di ãye gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
26 Emi ti sọ̀rọ ọ̀na mi, iwọ sì gbohùn mi : ma kọ́ mi ni aṣẹ rẹ.
27 Mu oyé ọ̀na ẹkọ́ rẹ yé mi : bẹ̃li emi o ma sọ̀rọ iṣẹ́ iyanu rẹ.
28 Ọkkàn mi nro fu ãrẹ̀ : iwọ mu mi lara le gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
29 Mu ọ̀na eke kuro lọdọ mi : ki o sì fi ore-ọfẹ fi ofin rẹ fu mi.
30 Emi ti yàn ọ̀na otitọ : idajọ́ rẹ ni mo fi lelẹ niwaju mi.
31 Emi ti faramọ́ ẹ̀rí rẹ : Jehofa, má ṣe dojutì mi.
32 Emi o ma súre lọ nipa ofin rẹ, nigbati iwọ ba bù àiya mi laye.

Digitized by Google

OWURỌ IJỌ. 25.

He.

33 Jehofa, kọ́ mi li ọ̀na aṣẹ rẹ; emi o sì ma pa a mọ́ de opin.
34 Fu mi li oyé, emi o sì ma pa ofin rẹ mọ́; nitõtọ, emi o ma kiye si i tinu-tinu mi gbogbo.
35 Mu mi rìn nipa ofin rẹ; nitori ninu rẹ̀ ni didùn-inu mi.
36 Fà àiya mi si ẹrí rẹ, ki o má sì ṣe si oju-kòkoro.
37 Yi oju mi pada kuro lati ma wò ohun asan; ki o sì mu mi yara nipa ọ̀na rẹ.
38 Fi ọ̀rọ rẹ mulẹ si iranṣẹ rẹ, ti o fi ori fu ìbẹ̀ru rẹ.
39 Yi ẹ̀gan mi pada ti mo bẹ̀ru : nitori ti idajọ́ rẹ dara.
40 Kiye si i, ọkkàn mi ti fà si ẹkọ́ rẹ : mu ara mi ya nipa ododo rẹ.

Fau.

41 Jẹ ki ànu rẹ ki o tọ̀ mi wá pẹlu, Jehofa, ani igbala rẹ, gẹ̀gẹ̀ bi ọ̀rọ rẹ.
42 Bẹ̀li emi o ni ọ̀rọ ti emi o fi da awọn ti ngàn mi lohùn; nitori ti mo gbẹ̀kẹ̀le ọ̀rọ rẹ.
43 Má sì ṣe gbà ọ̀rọ otitọ kuro li ẹnu mi patapata; nitori ti mo ti nṣe ireti ni idajọ́ rẹ.
44 Bẹ̀li emi o ma pa ofin rẹ mọ́ pẹ̀ titi lai ati lailai.
45 Bẹ̀li emi o ma rìn nigbangba : nitori ti mo wá ẹkọ́ rẹ.
46 Emi o ma sọ̀rọ ẹrí rẹ pẹlu niwaju awọn ọba, emi kì yio sì tiju.

Digitized by Google

47 Emi o sì ma ṣe inu-didùn ninu ofin rẹ̀, ti emi ti fẹ́.
48 Ọwọ́ mi pẹ̀lu li emi o gbé soke si ofin rẹ̀, ti emi ti fẹ́; emi o sì ma ṣe iṣaro aṣẹ rẹ̀.

Sain.

49 Ranti ọ̀rọ̀ ni si ọmmọ ọdọ rẹ̀, lara eyi ti iwọ ti mu ṣe ireti.
50 Eyi ni itunu mi ninu ipọnju mi : nitori ọ̀rọ̀ rẹ̀ li o mu mi lara ya.
51 Awọn agberaga ti nyọ̀-sùti si mi gidigidi : ṣugbọn emi kò fà sẹ̀hin kuro nipa ofin rẹ̀.
52 Jehofa, emi ranti idajọ́ rẹ̀ atijọ́; emi sì tù ara mi ninu.
53 Ẹ̀ru nla bà mi nitori awọn enia buburu ti o kọ̀ ofin rẹ̀ silẹ̀.
54 Aṣẹ rẹ̀ li o ti nṣe orin mi ni ile atipo mi,
55 Emi ti ranti orukọ rẹ̀, Jehofa, li oru, emi sì ti pa ofin rẹ̀ mọ́.
56 Eyi ni mo ni, nitori ti mo pa ẹkọ́ rẹ̀ mó.

Keti.

57 Jehofa, iwọ ni ipín mi : emi ti wipe emi o pa ọ̀rọ̀ rẹ̀ mọ́.
58 Emi ti mbẹ̀bẹ̀ oju-rere rẹ̀ tinu-tinu mi gbogbo : ṣãnu fu mi gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ rẹ̀.
59 Emi rò ọna mi, mo sì yi ẹsẹ̀ mi pada si ẹ̀rí rẹ̀.
60 Emi yara, emi kò sì duro lati pa ofin rẹ̀ mọ́.
61 Awọn ẹgbẹ̀ ti awọn enia buburu ti jà mi li olè : ṣugbọn emi kò gbagbé ofin rẹ̀.
62 Larin ọganjọ́ emi o dide lati dupẹ̀ fu ọ nitori ododo idajọ́ rẹ̀.

Digitized by Google

63 Ẹgbẹ gbogbo awọn ti o bẹ̀ru rẹ li emi, ati ti awọn ti npa ẹkọ́ rẹ mọ́.
64 JEHOFA, aiye kún fu ãnu rẹ : kọ́ mi li aṣẹ rẹ.

TETI.

65 Iwọ ti nṣe rere fu iranṣẹ rẹ, JEHOFA, gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
66 Kọ́ mi ni idajọ́ ati ìmọ rere : nitori ti mo gbà ofin rẹ gbọ́.
67 Ki a to pọ́n mi loju emi ti ṣìna : ṣugbọn nisisiyi emi pa ọ̀rọ rẹ mọ́.
68 Iwọ ṣeun, iwọ sì nṣe rere; kọ́ mi li aṣẹ rẹ.
69 Awọn agberaga ti ṣe eke si mi : ṣugbọn emi o pa ẹkọ́ rẹ mọ́ tinu-tinu mi gbogbo.
70 Àiya wọn li ọ̀rá bi epo; ṣugbọn mo ṣe inu-didùn ninu ofin rẹ.
71 O dara fu mi ti a pọ́n mi loju; ki emi ki o le kọ́ aṣẹ rẹ.
72 Ofin ẹnu rẹ o ya mi lara jù ẹgbẹgbẹrun wura ati fadaka lọ.

ALẸ IJỌ. 25.

JODU.

73 Ọwọ́ rẹ li o ti da mi ti o sì ṣe aworan mi : fu mi li oyé, ki emi ki o le kọ́ ofin rẹ.
74 Inu awọn ti o bẹ̀ru rẹ yio dùn nigbati nwọn ba ri mi; nitori ti mo ti reti li ọ̀rọ rẹ.
75 JEHOFA, emi mọ̀ pe, ododo ni idajọ́ rẹ, ati pe li otitọ ni iwọ pọ́n mi loju.
76 Emi bẹ̀ ọ, jẹ ki iṣeun ãnu rẹ ki o ma ṣe itunu mi, gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ si iranṣẹ rẹ.

Digitized by Google

77 Jẹ ki irọnu ãnu rẹ ki o tọ mi wá, ki emi ki o wà lãye : nitori ofin rẹ ni didùn-inu mi.
78 Jẹ ki oju ki o tì agberaga; nitori ti nwọn ṣe òdi si mi li alnidi : ṣugbọn emi o ma ṣe aṣaro ninu ẹkọ́ rẹ.
79 Jẹ ki awọn ti o bèru rẹ ki o yipada si mi, ati awọn ti o ti mọ ẹrí rẹ.
80 Jẹ ki àiya mi ki o yè li aṣẹ rẹ; ki oju ki o má ṣe tì mi.

Kafu.

81 Ọkkàn mi ndaku nitori igbala rẹ : ṣugbọn emi ni ireti li ọrọ rẹ.
82 Oju mi ṣofo nitori ọrọ rẹ, wipe, Nigbawo ni iwọ o tù mi ninu?
83 Nitori ti emi dà bi ìgo awọ loju ẽfin; ṣugbọn emi kò gbagbé aṣẹ rẹ.
84 Ijọ melo li ọjọ iranṣẹ rẹ? nigbawo ni iwọ o ṣe idajọ́ lara awọn ti nṣe inunibini si mi?
85 Awọn agberaga ti wà ihò silẹ dè mi, ti kò si nipa ofin rẹ.
86 Otitọ li ofin rẹ gbogbo : nwọn fi àitọ ṣe inunibini si mi; iwọ ràn mi lọwọ́.
87 Nwọn fẹrẹ run mi li ori ilẹ; ṣugbọn emi kò kọ ẹkọ́ rẹ silẹ.
88 Mu mi lara ya nipa iṣeun-ifẹ́ rẹ; bẽli emi o pa ẹrí ẹnu rẹ mọ́.

Lamedi.

89 Jehofa, lai, ọrọ rẹ kalẹ li ọrun.
90 Lati iran-diran li otitọ rẹ : iwọ ti fi idi aiye mulẹ, o sì duro.
91 Nwọn duro di oni nipa ìlana rẹ : nitori pe iranṣẹ rẹ ni gbogbo wọn.

Digitized by Google

92 Bikoṣepe bi ofin rẹ ti ṣe inu-didùn mi, emi iba ti ṣegbé ninu ipọnju mi.
93 Lai emi kì yio gbagbé ẹkọ́ rẹ : nitori pe awọn ni iwọ fi mu mi lara ya.
94 Tì rẹ li emi, gbà mi là ; nitori ti emi wá ẹkọ́ rẹ.
95 Awọn enia buburu ti duro dè mi lati pa mi : ṣugbọn emi o rò ẹrí rẹ.
96 Emi ti ri opin pipé gbogbo : ṣugbọn ofin rẹ li o gbòro gidigidi.

MEMI.

97 Emi ti fẹ ofin rẹ to ! iṣaro mi ni li ọjọ gbogbo.
98 Nipa ofin rẹ iwọ mu mi gbọ́n jù awọn ọtá mi lọ : nitori ti o wà pẹlu mi nigba-gbogbo.
99 Emi ni iyè ninu jù gbogbo awọn olukọ́ mi lọ : nitori pe ẹrí rẹ ni iṣaro mi.
100 Oyé yé mi jù awọn àgba lọ, nitori ti mo pa ẹkọ́ rẹ mọ́.
101 Mo ti fà ẹsẹ mi sẹhin kuro nipa ọna ibi gbogbo, ki emi ki o le pa ọrọ rẹ mọ́.
102 Emi kò yà kuro ni idajọ́ rẹ : nitori pe iwọ li o kọ́ mi.
103 Ọrọ rẹ ti dùn mọ́ mi li ẹnu to ! jù oyin lọ li ẹnu mi !
104 Nipa ẹkọ́ rẹ emi ni iyè ninu : nitorina mo korira ọna eke gbogbo.

OWURỌ́ IJỌ. 26.

NUN.

105 Ọrọ rẹ ni fitila si mi li ẹsẹ, ati imọlẹ si ipa ọna mi.

Digitized by Google

106 Emi ti bura, emi o sì mu u ṣẹ, pe emi o pa idajọ ododo rẹ mọ́.
107 A pọ́n mi loju gidigidi : JEHOFA, mu mi lara ya, gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
108 Emi bẹ ọ JEHOFA gbà ọrẹ atinuwa ẹnu mi, ki o sì kọ́ mi ni idajọ́ rẹ.
109 Ọkkàn mi wà lọwọ́ mi nigba-gbogbo : ṣugbọn emi ko gbagbé ofin rẹ.
110 Awọn enia buburu ti dẹkùn silẹ fu mi : ṣugbọn emi kò ṣìna kuro nipa ẹkọ́ rẹ.
111 Ẹ̀rí rẹ ni mo gbá mu bi ogún lailai : nitori awọn li ayọ̀ inu mi.
112 Emi ti fà àiya mi si ati pa aṣẹ rẹ mọ́ nigba-gbogbo, ani de opin.

SAMEKI.

113 Emi korira ìronu asan : ṣugbọn ofin rẹ ni mo fẹ.
114 Iwọ ni ibi ipamọ́ mi ati asà mi : emi nṣe ireti ninu ọ̀rọ rẹ.
115 Kuro lọdọ mi ẹnyin oluṣe-buburu : nitori ti emi o pa ofin Ọlọrun mi mọ́.
116 Gbé mi soke nipa ọ̀rọ rẹ̀, ki emi ki o yè : ki o má sì jẹ ki oju ireti mi ki o tì mi.
117 Iwọ gbé mi soke, emi o sì wà li allewu ; emi o sì ma juba aṣẹ rẹ nigba-gbogbo.
118 Iwọ ti tẹ gbogbo awọn ti o ṣìna kuro nipa aṣẹ rẹ mọlẹ : nitori pe eke li ẹ̀tan wọn.
119 Iwọ ṣa gbogbo awọn enia buburu aiye tì bi idarọ : nitorina emi fẹ ẹ̀rí rẹ.
120 Ara mi wa-rìri nitori ìbẹru rẹ; emi sì bẹ̀ru idajọ́ rẹ.

AIN.

121 Emi ti ṣe idajọ́ ati otitọ : má ṣe jọwọ́ mi lọwọ́ fu awọn aninilara mi.

Digitized by Google

122 Ṣe onigbọwọ fu iranṣẹ rẹ fu rere : má ṣe jẹ ki awọn agberaga ki o ni mi lara.
123 Oju kọn mi nitori igbala rẹ, ati nitori ọrọ ododo rẹ.
124 Ṣe si iranṣẹ rẹ gẹgẹ bi ãnu rẹ, ki o sì kọ́ mi li aṣẹ rẹ.
125 Iranṣẹ rẹ li emi ; fu mi li oyé, ki emi ki o le mọ ẹrí rẹ.
126 Jehofa, o tọ́ akokò fu ọ lati ṣiṣẹ : nitori ti nwọn ti sọ ofin rẹ di ofo.
127 Nitorina emi fẹ ofin rẹ jù wura, nitõtọ, jù wura didara lọ.
128 Nitorina emi buyìn fu gbogbo ẹkọ́ rẹ si otitọ li ohun gbogbo : emi sì korira gbogbo ọna eke.

Pe.

129 Iyanu li ẹrí rẹ : nitorina li ọkkàn mi ṣe pa wọn mọ́.
130 Iwọle ọrọ rẹ fu-ni ni imọlẹ ; o sì fi oyé fu awọn òpe.
131 Emi ya ẹnu mi, ẹmmí mi hẹlẹ : nitori ti ọkkàn mi fà si ofin rẹ.
132 Iwọ bojuwò mi, ki o sì ṣãnu fu mi, gẹgẹ bi iṣe rẹ si awọn ti o fẹ orukọ rẹ.
133 Ṣe ìlana ẹsẹ mi ninu ọrọ rẹ : ki o má sì jẹ ki èṣẹ kan ki o jọbba mi.
134 Gbà mi lọwọ́ ininilara enia : bẽli emi o sì ma pa ẹkọ́ rẹ mọ́.
135 Ṣe oju rẹ ki o mọlẹ si iranṣẹ rẹ lara ; ki o sì kọ́ mi li aṣẹ rẹ.
136 Odò omi nṣàn silẹ li oju mi, nitori ti nwọn kò pa ofin rẹ mọ́.

Sadi.

137 Olododo ni iwọ, Jehofa, ati diduro ṣinṣin ni idajọ́ rẹ.

Digitized by Google

138 Ẹ̀rí rẹ ti iwọ ti pa laṣẹ, ododo ati otitọ ni gidigidi.
139 Itara mi ti pa mi run tan, nitori ti awọn ọtá mi ti gbagbé ọ̀rọ rẹ.
140 Funfun li ọ̀rọ rẹ : nitorina ni iranṣẹ rẹ ṣe fẹ ẹ.
141 Emi kére ati ẹni ègan ni : ṣugbọn emi kò gbagbé ẹkọ́ rẹ.
142 Ododo rẹ lailai ododo ni, otitọ sì li ofin rẹ.
143 Iyọnu ati àrokan dì mi mu : ṣugbọn ofin rẹ ni inu-didùn mi.
144 Ododo ti ẹ̀rí rẹ aiye-raiye ni : fu mi li oyé, emi o sì yè.

ALẸ IJỌ. 26.

KOFU.

145 Tinu-tinu mi gbogbo ni mo fi kigbe; JEHOFA, gbohùn mi : emi o pa aṣẹ rẹ mọ́.
146 Emi kigbe si ọ; gbà mi là, emi o sì ma pa ẹ̀rí rẹ mọ́.
147 Emi ṣaju kutukutu owurọ̀, emi nke : emi ṣe ireti ninu ọ̀rọ rẹ.
148 Oju mi ṣaju iṣọ́ oru, ki emi ki o le ma ṣe iṣaro ninu ọ̀rọ rẹ.
149 Gbohùn mi gẹgẹ bi iṣeun-ifẹ rẹ : JEHOFA, mu mi lara ya gẹgẹ bi idajọ́ rẹ.
150 Awọn ti ntọ̀ ìwa-buburu lẹhin sumọ́ itosi : nwọn jìna si ofin rẹ.
151 JEHOFA, iwọ wà ni itosi : otitọ sì ni gbogbo ofin rẹ.
152 Nitì ẹ̀rí rẹ, emi ti mọ̀ nigba atijọ pe iwọ ti fi idi wọn mulẹ lailai.

Digitized by Google

Reṣi.

153 Rò ti ipọnju mi, ki o sì gbà mi : nitori ti emi kò gbagbé ofin rẹ.
154 Gbà ẹjọ́ mi rò, ki o sì gbà mi : mu mi lara ya gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
155 Igbala jìna si awọn enia buburu : nitori ti nwọn kò wá aṣẹ rẹ.
156 Ọ̀pọ ni irọnu ãnu rẹ, Jehofa : mu mi lara ya gẹgẹ bi idajọ́ rẹ.
157 Ọ̀pọ li awọn oninunibini mi ati awọn ọtá mi; ṣugbọn emi kò fà sẹhin kuro niti ẹrí rẹ.
158 Emi wò awọn olurekọja, inu mi sì bajẹ; nitori ti nwọn kò pa ọ̀rọ rẹ mọ́.
159 Rò bi emi ti fẹ ẹkọ́ rẹ : Jehofa, mu mi lara ya, gẹgẹ bi iṣeun-ifẹ́ rẹ.
160 Otitọ li ọ̀rọ rẹ lati ipilẹṣẹ : ati olukuluku idajọ́ ti ododo rẹ duro lailai.

Sin.

161 Awọn ọmmọ-alade ṣe inunibini si mi li alnidi : ṣugbọn àiya mi duro ninu ẹ̀ru ọ̀rọ rẹ.
162 Emi yọ̀ si ọ̀rọ rẹ, bi ẹniti o ri ọ̀rọ̀ pipọ̀.
163 Emi korira, mo sì ṣe hõ si eke ṣiṣe : ṣugbọn ofin rẹ ni mo fẹ.
164 Nigba meje li ọjọ li emi nyìn ọ nitori ododo idajọ́ rẹ.
165 Alafia pupọ̀ li awọn ti o fẹ ofin rẹ ni : kò sì si ohun kan ti yio bà wọn ninu jẹ.
166 Jehofa, emi ti nreti igbala rẹ, emi sì ṣe ofin rẹ.
167 Ọkkàn mi ti pa ẹrí rẹ mọ́; emi sì fẹ wọn gidigidi.
168 Emi ti npa ẹkọ́ rẹ, ati ẹrí rẹ mọ́ : nitori ti gbogbo ọ̀na mi mbẹ niwaju rẹ.

Digitized by Google

TAU.

169 JEHOFA, jẹ ki ẹkún mi ki o sun siwaju rẹ : fu mi li oyé gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
170 Jẹ ki ẹ̀bẹ mi ki o wá siwaju rẹ : gbà mi gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.
171 Ète mi yio fi iyìn hàn, nigbati iwọ ba ti kọ́ mi li aṣẹ rẹ.
172 Ahọn mi yio sọ niti ọ̀rọ rẹ : nitori pe ododo ni gbogbo ofin rẹ.
173 Jẹ ki ọwọ́ rẹ ki o ràn mi lọwọ́ ; nitori ti mo ti yàn ẹkọ́ rẹ.
174 JEHOFA, ọkkàn mi ti fà si igbala rẹ ; ofin rẹ sì ni didùn-inu mi.
175 Jẹ ki ọkkàn mi ki o wà lãye, yio sì ma yìn ọ ; sì jẹ ki idajọ́ rẹ ki o ma ràn mi lọwọ́.
176 Emi ti ṣìna kiri bi agutan ti o nu ; wá iranṣẹ rẹ ; nitori ti emi kò gbagbé ofin rẹ.

OWURỌ IJỌ. 27.

PSALMU 120.

NINU ipọnju mi emi kepè JEHOFA, o sì gbohùn mi.
2 JEHOFA, gbà ọkkàn mi, lọwọ́ eke ète, ati lọwọ́ ahọn eke ?
3 Kini ki a fi fu ọ ? tabi kini ki a ṣe si ọ, iwọ ahọn eke ?
4 O dabi ọfà mimu alagbara, ti on ti ogun-ná igi juniperi.
5 Egbé ni fu mi, ti mo ṣe atipo ni Meṣeki, ti mo joko ninu agọ́ Kedari !
6 Ọkkàn mi ti ba ẹniti o korira alafia gbé pẹ.

Digitized by Google

7 Alafia ni mo mu : ṣugbọn nigbati mo ba sòrọ, ti ìja ni ti wọn.

PSALMU 121.

EMI o gbé oju mi si ori òke ni, nibi ti iranlọwọ mi ti mbọ̀.

2 Iranlọwọ mi ti ọwọ́ JEHOFA wá, ti o da ọrun on aiye.

3 On kì yio jẹ ki ẹsẹ rẹ ki o yè : ẹniti npa ọ mọ́ kì yio togbé.

4 Kiye si i, ẹniti npa Israeli mọ́ kì yio togbé bẽni kì yio sùn.

5 JEHOFA li olupamọ́ rẹ : JEHOFA li ojiji rẹ li ọwọ́ ọtún rẹ.

6 Õrùn kì yio pa ọ nigba ọsán, tabi oṣupa nigba oru.

7 JEHOFA yio pa ọ mọ́ kuro ninu ibi gbogbo : yio pa ọkkàn rẹ mọ́.

8 JEHOFA yio pa alọ ati àbọ rẹ mọ́ lati igba yi lọ, ati siwaju lailai.

PSALMU 122.

INU mi dùn nigbati nwọn wi fu mi pe, Ẹ jẹ ki a lọ si ile JEHOFA.

2 Ẹsẹ wa yio duro ninu ẹnu ọ̀na rẹ, iwọ Jerusalemu.

3 A kọ́ Jerusalemu bi ilu-nla ti o fi ara mọra pọ̀ :

4 Nibiti awọn ẹ̀ya ni ima gòke lọ, awọn ẹ̀ya JEHOFA, si ibi ẹrí Israeli, lati ma dupẹ fu orukọ JEHOFA.

5 Nitori ibẹ̀ li a gbé awọn itẹ́ idajọ́ kalẹ, awọn itẹ́ ti ile Dafidi.

6 Gbadura fu alafia Jerusalemu : awọn ti o fẹ ọ yio ṣe rere.

Digitized by Google

7 Ki alafia ki o wà ninu ile rẹ, ati ire ninu afin rẹ.
8 Nitori awọn arakọnri ati awọn ẹgbẹ mi, emi o wi nisisiyi pe, Alafia pẹlu rẹ.
9 Nitori ti ile JEHOFA, Ọlọrun wa emi o ma wá ire rẹ.

PSALMU 123.

IWỌ ni mo gbé oju mi soke si, iwọ ti ngbé inu awọn ọrun.
2 Kiye si i, bi oju awọn iranṣẹ ọkọnri ti ima wò ọwọ́ awọn babba wọn, ati bi oju iranṣẹ obiri ti ima wò ọwọ́ iya rẹ̀; bẽli oju wa nwò JEHOFA Ọlọrun wa, titi yio fi ṣãnu fu wa.
3 JEHOFA, ṣãnu fu wa, ṣãnu fu wa : nitori ti a kún fu ẹgan pupọ̀-pupọ.
4 Ọkkàn wa kún pupọ̀-pupọ fu ẹgan awọn ti o wà ni irọra, ati fu ẹgan awọn agberaga.

PSALMU 124.

IBA má ṣe pe JEHOFA ti o ti wà ni ti wa, ni ki Israeli ki o ma wi nisisiyi;
2 Iba má ṣe pe JEHOFA ti o ti wà ni ti wa, nigba ti awọn enia duro si wa :
3 Nigbana ni nwọn iba gbé wa mì lãye, nigbati ibinu wọn ru si wa :
4 Nigbana li omi wọn-ni iba bò wa mọlẹ, ìṣan-omi iba ti bori ọkkàn wa :
5 Nigbana li agberaga omi iba bori ọkkàn wa.
6 Olubukún ni JEHOFA, ti kò fi wa fu wọn bi ohun ọdẹ fu ehin wọn.
7 Ọkkàn wa yọ bi ẹiyẹ jade kuro ninu okùn apẹïyẹ : okùn já, awa sì yọ.
8 Iranlọwọ wa mbẹ li orukọ JEHOFA, ti o da ọrun on aiye.

Digitized by Google

PSALMU 125.

AWỌN ti o gbẹkẹle JEHOFA yio dabi òke Sion, ti a kò le ṣí ni idi, bikoṣepe o duro lailai.

2 Bi òke nla ti yi Jerusalemu ká kiri, bẽli JEHOFA yi awọn enia rẹ̀ ká kiri lati isisiyi lọ ati lailai.

3 Nitori ti ọpá awọn enia buburu kì yio bà le ipín awọn olododo; ki awọn olododo ki o má ba fi ọwọ́ wọn le èṣẹ.

4 JEHOFA, ṣe rere, fu awọn ẹni rere, ati fu awọn ti àiya wọn duro ṣinṣin.

5 Bi o ṣe ti irú awọn ti nwọn nyipada si ipa ọ̀na wíwọ wọn; JEHOFA yio fà wọn jade pẹlu awọn oniṣẹ̀ èṣẹ : ṣugbọn alafia yio wà lori Israeli.

ALẸ IJỌ. 27.

PSALMU 126.

NIGBATI JEHOFA ṣe ayipada ikolọ ti Sion, awa dabi ẹniti nla alá.

2 Nigbana li ẹnu wa kún fu ẹrin, ati ahọn wa fu orin : nigbana ni nwọn wi ninu awọn keferi pe, JEHOFA ṣe ohun nla fu wọn.

3 JEHOFA ṣe ohun nla fu wa; nitori ohun ti awa nyọ̀.

4 JEHOFA ṣe ayipada ikolọ wa, bi ìṣan-omi ni gusù,

5 Awọn ti nfi omije fọn irugbin yio fi ayọ̀ ká.

6 Ẹniti nsọkun lọ, ti nso eso irú iyebiye, li aìṣiye-meji yio tún fi ayọ̀ pada wa, yio ma mu ití rẹ̀ wá pẹlu rẹ̀.

Digitized by Google

Psalmu 127.

BIKOṢEPE Jehofa ba kọ́ ile na, awọn ti nkọ́ ọ nṣiṣẹ lasan : bikoṣepe Jehofa ba pa ilu-nla na mọ́, oluṣọ jí lasan.

2 Asan ni fu ọ lati dide ni kutukutu, lati joko di àjiji, lati jẹ onjẹ ikãnu : bẹ̃li o nfi orun fu olufẹ rẹ̀.

3 Kiye si i, awọn ọmmọ ni ini ti Jehofa : ọmmọ inu sì li ère rẹ̀.

4 Bi ọfà ti ri li ọwọ́ alagbara, bẹ̃li awọn ọmmọ ewe.

5 Ibukún ni fu ọkọnri na ti apo rẹ̀ kún fu wọn : oju kì yio tì wọn, ṣugbọn nwọn o ṣẹgun awọn ọtá li ẹnu ọ̀na.

Psalmu 128.

IBUKÚN ni fu gbogbo ẹniti o bẹ̀ru Jehofa; ti o sì nrìn li ọ̀na rẹ̀.

2 Nitori ti iwọ o jẹ iṣẹ́ ọwọ́ rẹ : ninu irọra ni iwọ o sì ma gbé, yio sì dara fu ọ.

3 Obiri rẹ yio dabi ajara rere eleso pipọ̀ li ẹgbẹ ile rẹ : awọn ọmmọ rẹ yio dabi igi oróro yi tabeli rẹ ká.

4 Kiye si i, pe bẹ̃li a o busi i fu ọkọnri na, ti o bẹ̀ru Jehofa.

5 Jehofa yio busi i fu ọ lati Sion wá, ki iwọ ki o sì ma ri ire Jerusalemu li ọjọ aiye rẹ gbogbo.

6 Bẹ̃ni ki iwọ ki o sì ma ri ati ọmmọ de ọmmọ rẹ; ati alafia lara Israeli.

Psalmu 129.

IGBA pupọ̀ ni nwọn ti npọ́n mi loju lati igba ewe mi wá, ni ki Israeli ki o wi nisisiyi.

Digitized by Google

2 Igba pupọ̀ ni nwọn ti npọ́n mi loju lati igba ewe mi wá : ṣugbọn nwọn kò ti bori mi.

3 Awọn ìwalẹ̀ wàlẹ̀ si ẹ̀hin mi : nwọn sì là aporo wọn gigùn.

4 Olododo ni JEHOFA : o ti ke okùn awọn enia buburu li agbede-meji.

5 Ki gbogbo awọn ti o korira Sion ki o damu, ki nwọn ki o yi ẹ̀hin pada.

6 Ki nwọn ki o dabi koriko oke àja, ti o gbẹ̀ dànu kì o to dàgba soke :

7 Ninu eyi ti oloko pipa kò kún ọwọ́ rẹ̀ ; bẹ̀li ẹniti ndì ití kò kún àiya rẹ̀.

8 Bẹ̀li awọn ti nkọja lọ kò wipe, Ibukún JEHOFA ki o pẹ̀lu nyin : awa sùre fu nyin li orukọ JEHOFA.

PSALMU 130.

LATI inu ibú wá li emi kepè ọ, JEHOFA.

2 OLUWA, gbohùn mi : jẹ ki etí rẹ ki o tẹ̀ silẹ̀ si ohùn ẹ̀bẹ̀ mi.

3 JEHOFA, iba ṣepe ki iwọ ki o ma ṣami ẹ̀ṣẹ̀, OLUWA tani iba duro ?

4 Ṣugbọn idariji wà lọdọ rẹ̀, ki a le ma bẹ̀ru rẹ̀.

5 Emi duro dè JEHOFA, ọkkàn mi duro, ati ninu ọ̀rọ̀ rẹ̀ li awa nṣe ireti.

6 Ọkkàn mi duro dè JEHOFA jù awọn ti nṣọna owurọ̀ lọ : ani jù awọn ti nṣọna owurọ̀ lọ.

7 Jẹ ki Israeli ki o ni ireti niti JEHOFA : nitori pe lọdọ JEHOFA li ãnu wà, ati lọdọ rẹ̀ li ọ̀pọ̀lọpọ̀ idande.

8 Yio sì da Israeli nide kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ gbogbo.

Digitized by Google

PSALMU 131.

JEHOFA, àiya mi kò gberaga, bẹ̃li oju mi kò gbé soke : bẹ̃li emi kò fi ọwọ́ mi le ỳran nla, tabi si ohun ti o ga jù mi lọ.

2 Nitõtọ emi nṣọ ara mi emi sì mu ọkkàn ara mi dakẹjẹ, bi ọmmọ ti ati ọwọ́ iya rẹ̀ gbà li ẹnu ọmu : ọkkàn mi ri gẹ bi ọmmọ ti a já li ẹnu ọmu.

3 Jẹ ki Israeli ki o ni ireti niti JEHOFA lati isisiyi lọ ati lailai.

OWURỌ́ IJỌ. 28.

PSALMU 132.

JEHOFA, ranti Dafidi, ati gbogbo ipọnju rẹ̀ :

2 Bi o ti bura fu JEHOFA, ti o sì ṣe ileri ifẹ́ fu Ọlọrun alagbara Jakobu pe,

3 Nitõtọ, emi kì yio wọ̀ inu agọ́ ile mi lọ, bẹ̃li emi kì yio gùn ori akete mi ;

4 Emi kì yio fi orun fu oju mi, tabi ogbé fu ipenpeju mi,

5 Titi emi o fi ri ibi fu JEHOFA, ibujoko fu Ọlọrun agbara Jakobu.

6 Kiye si i, awa gburó rẹ̀ ni Efrata : awa ri i ninu igbẹ́ igi na.

7 Awa o lọ sinu agọ́ rẹ̀ : awa o ma sìn nibi apoti itisẹ rẹ̀.

8 JEHOFA, dide si ibi isimi rẹ ; iwọ, ati apoti agbara rẹ.

9 Ki a fi ododo wọ̀ awọn alufa rẹ ; ki awọn enia mimọ́ rẹ ki o ma hó fu ayọ̀.

10 Nitori ti Dafidi iranṣẹ rẹ má ṣe yi oju ẹni atorórosi rẹ pada.

Digitized by Google

11 JEHOFA ti bura nitõtọ fu Dafidi; on kì yio yipada kuro ninu rẹ̀; Ninu irú-ọmmọ ara rẹ̀ li emi o gbé kalẹ̀ si ori itẹ́ rẹ̀.
12 Bi awọn ọmmọ rẹ̀ yio ba pa majẹmu mi mọ́ ati ẹrí mi ti emi o kọ́ wọn, awọn ọmmọ wọn pẹlu yio joko lori itẹ́ rẹ̀ lailai.
13 Nitori ti JEHOFA ti yàn Sion; o ti fẹ ẹ fu ibujoko rẹ̀.
14 Eyi ni isimi mi lailai; nihin li emi o ma gbé; nitori ti mo fẹ ẹ.
15 Emi o bukún onjẹ rẹ̀ pupọ̀-pupọ : emi o fi onjẹ tẹ́ awọn talakà rẹ̀ lọrùn.
16 Emi o sì fi igbala wọ̀ awọn alufa rẹ̀; awọn enia mimọ́ rẹ̀ yio ma hó fu ayọ̀.
17 Nibẹ̀ li emi o gbé mu iwo Dafidi là, emi ti ṣe ìlana fitila kan fu ẹni atorórosi mi.
18 Awọn ọtá rẹ̀ li emi o fi ìtiju wọ̀ : ṣugbọn lara on tikara rẹ̀ li ade rẹ̀ yio ma gbilẹ̀.

PSALMU 133.

KIYE si i, o ti dara o sì ti dùn to fu awọn arakọnri lati ma gbé iṣọkan pọ̀.
2 O dabi ohun ikunra iye-biye li ori, ti o ṣàn de ìrungbọn, ni ìrungbọn Aaron : ti o sì ṣàn si etí aṣọ rẹ̀;
3 Bi ìri òke Hermon, ati bi ìri ti o sẹ̀ sori awọn òke nla Sion : nitori nibẹ̀ ni JEHOFA gbé paṣẹ ibukún, ani ti ìye lailai.

PSALMU 134.

E KIYE si i, ẹ fi ibukún fu JEHOFA, gbogbo ẹnyin iranṣẹ ti JEHOFA, ẹniti o duro ni ile ti JEHOFA li oru.
2 Ẹ gbé ọwọ́ nyin soke ninu ibi mimọ́, ki ẹ sì fi ibukún fu JEHOFA.

Digitized by Google

3 JEHOFA ti o da ọrun on aiye ki o busi i fu ọ lati Sion wá.

PSALMU 135.

E YÌN JEHOFA. Ẹ yìn orukọ JEHOFA; ẹ yìn i, ẹnyin iranṣẹ JEHOFA.
2 Ẹnyin ti nduro ni ile ti JEHOFA, ninu agbala ti ile Ọlọrun wa,
3 Ẹ yìn JEHOFA; nitori ti JEHOFA ṣeun; ẹ kọnrin iyìn si orukọ rẹ̀; nitori ti o dùn.
4 Nitori ti JEHOFA ti yàn Jakobu fu ara rẹ̀, ati Israeli fu iṣura ãyo rẹ̀.
5 Nitori ti emi mọ̀ pe JEHOFA tobi, ati pe OLUWA wa jù gbogbo awọn ọlọrun lọ.
6 Ohun-kohun ti o ba wù JEHOFA, on ni iṣe li ọrun, ati li aiye, li okun, ati ni ibi ọgbọn gbogbo.
7 O mu ikuku gòke lati opin ilẹ wá; o da manamana fu òjo; o nmu afẹfẹ ti inu iṣura rẹ̀ wá.
8 Ẹniti o kọlù awọn akọbi ni Egipti, ati ti enia ati ti ẹranko.
9 Ẹniti o rán àmi ati iṣẹ́ iyanu si arin rẹ, iwọ Egipti, si ara Farao, ati si ara awọn iranṣẹ rẹ̀ gbogbo.
10 Ẹniti o kọlù awọn orilẹ ède nla, ti o sì pa awọn alagbara ọba;
11 Sihon ọba ti awọn Amorite, ati Ogu ọba Baṣan, ati gbogbo awọn ijọba Kanaan:
12 O sì fi ilẹ wọn fu-ni ni ini, ilẹ-ini fu Israeli awọn enia rẹ̀.
13 JEHOFA, orukọ rẹ duro lailai; JEHOFA, iranti rẹ lati iran-diran gbogbo.
14 Nitori ti JEHOFA yio ṣe idajọ́ awọn enia rẹ̀, yio sì ronupiwada fu ara rẹ̀ nipa ti awọn ọmọ ọdọ rẹ̀.

Digitized by Google

15 Fadaka on wura li ere ti awọn keferi, iṣẹ ọwọ́ enia.
16 Nwọn li ẹnu, ṣugbọn nwọn kò fi sọ̀rọ; nwọn li oju, ṣugbọn nwọn kò fi ri iran.
17 Nwọn li etí ṣugbọn nwọn kò fi gbọran; bẹ̃ni kò si ẹmmí kan li ẹnu wọn.
18 Awọn ti o ṣe wọn dabi wọn : bẽ sì li olukuluku ẹniti o gbẹkẹle wọn.
19 Ẹ fi ibukún fu JEHOFA, ẹnyin ara ile Israeli : ẹ fi ibukún fu JEHOFA ẹnyin ara ile Aaron :
20 Ẹ fi ibukún fu JEHOFA, ẹnyin ara ile Lefi : ẹnyin ti o bèru JEHOFA, ẹ fi ibukún fu JEHOFA.
21 Olubukún ni JEHOFA lati Sion wá, ti o ngbé Jerusalemu. Ẹ fi iyìn fu JEHOFA.

ALẸ IJỌ. 28.

PSALMU 136.

EFI ọpẹ́ fu JEHOFA; nitori ti o ṣeun; nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
2 Ẹ fi ọpẹ́ fu Ọlọrun awọn ọlọrun : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
3 Ẹ fi ọpẹ́ fu OLUWA awọn oluwa : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
4 Fu on nikan ti nṣe iṣẹ́ iyanu nla : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
5 Fu ẹniti o fi ọgbọ́n da awọn ọrun : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
6 Fu ẹniti o tẹ́ ilẹ̀ ga jù omi lọ : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
7 Fu ẹniti o da awọn imọlẹ nla : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
8 Õrùn lati jọbba ọsán : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :

Digitized by Google

9 Oṣupa ati ìrawǫ lati jǫbba oru : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
10 Fu ẹniti o kǫlù Egipti lara awǫn akǫbi wǫn : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
11 O sì mu Israeli jade kuro larin wǫn : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
12 Pẹlu ǫwǫ́ agbara, ati apa ninà : nitori ti ãnú rẹ̀ duro lailai.
13 Fu ẹniti o pín Okun pupa ni ìya : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
14 O sì mu Israeli kǫja lǫ larin rẹ̀ : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
15 Ṣugbǫn o bì Farao ati ogun rẹ̀ ṣubu ninu Okun pupa : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
16 Fu ẹniti o sìn awǫn enia rẹ̀ là aginjù já : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
17 Fu ẹniti o kǫlù awǫn ǫbba nla : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
18 O sì pa awǫn ǫbba olokikí : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
19 Sihon ǫbba ti awǫn Amorite : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
20 Ati Ogu ǫbba Baṣan : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
21 O sì fi ilẹ̀ wǫn fu-ni ni ini ; nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
22 Ilẹ̀-ini fu Israeli iranṣẹ̀ rẹ̀ : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
23 Ẹniti o ranti wa ni ìwa irẹ̀lẹ̀ wa : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
24 O sì da wa ni ìde lǫwǫ́ awǫn ǫtá wa : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai :
25 Ẹniti o nfi onjẹ̀ fu ẹda gbogbo : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.
26 Ẹ fi ǫpẹ́ fu Ǫlǫrun ǫrun : nitori ti ãnu rẹ̀ duro lailai.

Digitized by Google

Psalmu 137.

LI ẹba awọn odò Babilon, nibẹ̀ li awa gbé joko, nitõto, awa sọnkun, nigbati awa ranti Sion.

2 Awa fi dùru wa kọ́ si ori igi okùn ti o wà larin rẹ̀.

3 Nitoripe nibẹ̀ li awọn ti o kó wa ni igbekun bère orin lọwọ́ wa; ati awọn ti o fi wa ṣòfo bère idaraya, wipe, Ẹ kọn orin Sion kan fu wa.

4 Awa o ti ṣe kọn orin Jehofa ni ilẹ àjeji?

5 Jerusalemu, bi emi ba gbagbé rẹ, jẹ ki ọwọ́ ọtún mi ki o gbagbé ọgbọ́n rẹ̀.

6 Bi emi ko ba ranti rẹ, jẹ ki ahọn mi ki o lẹ̀ mọ́ èrigi mi; bi emi kò ba fi iyìn Jerusalemu ṣaju ori ayọ̀ mi gbogbo.

7 Jehofa, ranti awọn ọmmọ Edomu li ọjọ́ Jerusalemu; awọn ẹniti nwipe, Wó o palẹ, wó o palẹ, de ipilẹ̀ rẹ̀.

8 Iwọ ọmmọbiri Babilon, ẹniti a o bajẹ; ibukún ni fu ẹniti o san a fu ọ bi iwọ ti hù si wa.

9 Ibukún li ẹniti o mu ti o sì fi awọn ọmmọ wẹ́wẹ́ rẹ ṣán okuta.

Psalmu 138.

EMI o ma yìn ọ tinu-tinu mi gbogbo: niwaju awọn ọlọrun li emi o ma yìn ọ.

2 Emi o ma gbadura siha tempeli mimọ́ rẹ, emi o sì ma yìn orukọ rẹ nitori iṣeun-ifẹ́ rẹ ati otitọ rẹ: nitori iwọ gbé ọ̀rọ rẹ ga jù gbogbo orukọ rẹ lọ.

3 Li ọjọ́ ti mo kepè iwọ da mi lohùn, iwọ sì fi ipá mu mi lara le li ọkkàn mi.

Digitized by Google

4 Gbogbo awọn ọbba ti ilẹ aiye yio yìn ọ, Jehofa, nigbati nwọn ba gbọ́ ọ̀rọ ẹnu rẹ.
5 Nitõtọ, nwọn o ma kọnrin nipa ọ̀na Jehofa : nitori pe nla li ogo Jehofa.
6 Bi Jehofa tilẹ ga, ṣugbọn o juba awọn onirẹlẹ; ṣugbọn agberaga li o mọ̀ li òkere rere.
7 Bi emi tilẹ nrìn ninu ipọnju, iwọ ni yio mu mi lara ya : iwọ o nà ọwọ́ rẹ si ibinu awọn ọtá mi, ọwọ́ ọtún rẹ yio sì gbà mi là.
8 Jehofa yio mu ohun ti ṣe ti emi pé : Jehofa, ãnu rẹ duro lailai : má ṣe kọ̀ iṣẹ́ ọwọ́ ara rẹ silẹ.

OWURỌ̀ IJỌ. 29.

Psalmu 139.

JEHOFA, iwọ ti wadi mi, iwọ sì ti mọ̀ mi.
2 Iwọ mọ̀ ijoko mi ati idide mi, iwọ mọ̀ ọkkàn mi li ọ̀na jijin rere.
3 Iwọ yi ipa ọ̀na mi ká, ati ibulẹ mi, gbogbo ọ̀na mi di mimọ̀ fu ọ.
4 Nitori ti kò si ọ̀rọ kan li ahọn mi, kiye si i, Jehofa, iwọ mọ̀ ọ patapata.
5 Iwọ sé mi mọ́ lẹhin ati niwaju, iwọ sì fi ọwọ́ rẹ le mi.
6 Irú ìmọ yi ṣe ohun iyanu fu mi jù; o ga, emi kò le mọ̀ ọ.
7 Nibo li emi o gbé lọ kuro lọwọ́ ẹmmí rẹ? tabi nibo li emi o sáre kuro niwaju rẹ?
8 Bi emi ba goke lọ si ọrun, iwọ wà nibẹ̀ : bi mo ba sì tẹ́ ẹní mi li ọrun apadi, kiye si i, iwọ wà nibẹ̀.
9 Emi iba mu iyẹ́ apa ti owurọ̀, ki emi sì lọ joko niha opin okun;

Digitized by Google

10 Ani nibẹ̀ na li ọwọ́ rẹ yio fà mi, ọwọ́ ọtún rẹ yio sì dì mi mu.
11 Bi mo wipe, Nitõtọ òkunkun yio bò mi mọlẹ; oru yio tilẹ mọlẹ yi mi ká.
12 Nitõtọ, òkunkun kò pamọ́ lọdọ rẹ; ṣugbọn oru tàn imọlẹ bi ọsán : ati òkunkun ati ọsán, mejeji bakan na ni fu ọ.
13 Nitori iwọ li o ni ọkkàn mi : iwọ li o bò mi mọlẹ ninu iya mi.
14 Emi o yìn ọ; tẹru-tẹru ati tiyanu-tiyanu li a da mi : iyanu ni iṣẹ́ rẹ; eyini li ọkkàn mi mọ̀ daju-daju.
15 Ohun ara mi kò pamọ́ kuro lọdọ rẹ, nigbati a da mi ni ìkọkọ, ti a sì nṣiṣẹ mi li arabara niha isalẹ ilẹ aiye.
16 Oju rẹ ti ri ohun ara mi, ti o wà li alpé : ati ninu iwe rẹ li a ti kọ gbogbo ẹ̀ya mi si, li ọjọ ti a o mọ wọn, nigbati ọkan wọn kò ti si.
17 Ọlọrun ìro inu rẹ si mi ti ṣe iye-biye to! iye wọn ti pọ̀ to!
18 Emi iba kà wọn, nwọn jù iyanrin lọ ni iye : nigbati mo ba jí, emi wà lọdọ rẹ sibẹ̀.
19 Ọlọrun, iwọ o pa enia buburu nitõtọ : nitorina ẹ kuro lọdọ mi, ẹnyin ọkọnri ẹ̀jẹ.
20 Nitori ti nwọn nfi buburu sọ̀rọ si ọ, awọn ọtá rẹ sì npè orukọ rẹ li asan.
21 JEHOFA, njẹ emi kò korira awọn ti o korira rẹ? njẹ inu mi kò ha sì bajẹ si awọn ti o dide si ọ?
22 Emi korira wọn li akotan : emi kà wọn si awọn ọtá mi.
23 Ọlọrun, wadi mi, ki o sì mọ̀ àiya mi : dan mi wò, ki o sì mọ̀ ìro inu mi :
24 Ki o sì wò bi ipa ọ̀na ìwa-buburu kan ba wà ninu mi, ki o sì fi ẹsẹ mi le ọ̀na titi aiye.

Digitized by Google

Psalmu 140.

JEHOFA, gbà mi lọwọ́ ọkọnri buburu ni : yọ mi lọwọ́ ọkọnri alagbara ni ;

2 Ẹniti nrò ìwa ìka ni inu wọn ; nigbagbogbo ni nwọn nkojọ pọ̀ si mi fu ìja.

3 Nwọn ti pọ́n ahọn wọn bi ejò ; oró pamọlẹ mbẹ li abbẹ ète wọn.

4 Jehofa, pa mi mọ́ kuro lọwọ́ awọn enia buburu ; yọ mi kuro lọwọ́ ọkọnri alagbara ni ; ẹniti o ti pin-nu rẹ̀ lati bì ìrin mi ṣubu.

5 Awọn agberaga ti dẹkun silẹ fu mi, ati okùn ; nwọn ti nà àwọn niha ọ̀na ; nwọn ti kẹkun silẹ fu mi.

6 Emi wi fu Jehofa pe, Iwọ li Ọlọrun mi : Jehofa, gbọ́ ohùn ẹbẹ mi.

7 Jehofa Oluwa, agbara igbala mi, iwọ li o bò ori mi mọlẹ li ọjọ ogun.

8 Jehofa, má ṣe fi ifẹ́ awọn enia buburu fu wọn : má ṣe kún ọgbọ́n buburu rẹ̀ lọwọ́ ; ki nwọn ki o má ba gbé ara wọn ga.

9 Bi o ṣe ti ori awọn ti o yi mi ká kiri ni, jẹ ki ìka ti awọn ète ara wọn ki o bò wọn mọlẹ.

10 Jẹ ki oguna ṣuṣu ki o bọ́ si wọn lara : ki a wọ́ wọn lọ sinu iná ; sinu ọgbọn jijin, ki nwọn ki o má le dide mọ́.

11 Má ṣe jẹ ki alahọn buburu ki o fi ẹsẹ mulẹ li aiye : ibi ni yio ma dọdẹ ọkọnri alagbara ni lati bì i ṣubu.

12 Emi mọ̀ pe, Jehofa yio mu ọ̀ran ti olupọnju duro, ati are ti awọn talakà.

13 Nitõtọ awọn olododo yio ma fi ọpẹ́ fu orukọ rẹ̀ : awọn alaiya diduro yio ma gbé iwaju rẹ̀.

Digitized by Google

PSALMU 141.

JEHOFA, emi kigbe pè ọ : yara si ọdọ mi; fi etí si ohùn mi, nigbati mo ba nkepè ọ.

2 Jẹ ki adura mi ki o wá si iwaju rẹ bi turare; ati igbé ọwọ́ mi soke bi ẹbọ aṣalẹ.

3 JEHOFA, fi ẹṣọ siwaju ẹnu mi; pa ilẹkun ète mi mọ́.

4 Má ṣe fà àiya mi si ohun ibi kan, lati ma ba awọn ti nṣiṣẹ ẹṣẹ ṣiṣẹ buburu : má sì jẹ ki emi ki o jẹ ninu ohun didùn wọn.

5 Jẹ ki olododo ki o fi ifẹ́ lù mi; iṣeun ni yio jasi : jẹ ki o sì ba mi wi; oróro didara ni yio jasi, ti kì yio fọ́ mi lori : sibẹ adura mi yio sá wà niti jamba wọn.

6 Nigbati a ba bì awọn onidajọ wọn ṣubu ni ibi okuta, nwọn o gbọ́ ọ̀rọ mi; nitori ti nwọn dùn.

7 Egungun wa tàn kalẹ li ẹnu isà okú, bi ẹni ke ti a sì là igi sori ilẹ.

8 JEHOFA OLUWA, ṣugbọn oju mi mbẹ lara rẹ : lọdọ rẹ ni igbẹkẹle mi wà; má ṣe jọwọ ọkàn mi nihoho.

9 Pa mi mọ́ kuro ninu okùn ti nwọn dẹ silẹ fu mi, ati okùn ti awọn oniṣẹ ẹṣẹ.

10 Jẹ ki awọn enia buburu ki o bọ́ sinu àwọn ara wọn, nigbati emi ba kọja kuro.

ALẸ IJỌ. 29.

PSALMU 142.

JEHOFA ni mo fi ohùn mi kigbe pè; ohùn mi ni mo fi mbẹbẹ mi si JEHOFA.

2 Emi tú aroye mi silẹ niwaju rẹ; emi fi iṣẹ́ mi hàn niwaju rẹ.

Digitized by Google

3 Nigbati ọkkàn mi bò mọlẹ ninu mi, nigbana ni iwọ mọ ipa ọna mi. Li ọna ti emi nrìn ni nwọn dẹkun silẹ fu mi nikọ̀kọ.

4 Emi wò ọwọ́ ọtún mi, sì kiye si i, ṣugbọn kò si ẹnikan ti o jẹ mọ́ mi: àbo dẹtì fu mi; kò si ẹniti o náni ọkkàn mi.

5 JEHOFA, iwọ ni mo kigbe pè: emi wipe, iwọ li àbo mi ati ipín mi ni ilẹ ti awọn alãye.

6 Fiye si igbe mi; nitori ti a rẹ̀ mi silẹ gidigidi: gbà mi lọwọ́ awọn oninunibini mi; nitori ti nwọn lagbara jù mi lọ.

7 Mu ọkkàn mi jade kuro ninu tubu, ki emi ki o le ma yìn orukọ rẹ: awọn olododo yio yi mi ká kiri; nitori ti iwọ o fi ọ̀pọ̀lọpọ ba mi ṣe.

PSALMU 143.

JEHOFA, gbọ́ adura mi, fi etí si ẹ̀bẹ mi: ninu otitọ rẹ da mi lohùn, ati ninu ododo rẹ.

2 Ki o má sì ṣe ba iranṣẹ rẹ lọ sinu idajọ́: nitori ti kò sì ẹniti o wà lãye ti a o dalare niwaju rẹ.

3 Nitori ti awọn ọtá ti ṣe inunibini si mi; o ti lù ẹmmí mi bolẹ; o ti mu mi joko li òkunkun, bi awọn ti o ti kú pẹ.

4 Nitorina li emmí mi ṣe bò mọlẹ ninu mi; ofo fo àiya mi ninu mi.

5 Emi ranti ọjọ atijọ: emi ṣe aṣaro iṣẹ́ rẹ gbogbo; emi nronu iṣẹ́ ọwọ́ rẹ.

6 Emi nà ọwọ́ mi si ọ: ongbẹ rẹ ngbẹ ọkkàn mi bi ilẹ gbigbẹ.

7 JEHOFA, gbọ́ ti emi nisisiyi: o rẹ̀ ọkkàn mi tan: má ṣe pa oju rẹ mọ́ kuro lara mi, ki emi ki o má dabi awọn ti o lọ sinu ihò.

8 Mu mi gbọ́ iṣeun-ifẹ́ rẹ li owurọ̀; nitori

Digitized by Google

iwọ ni mo gbẹkẹlé : mu mi mọ̀ ọ̀na ti emi iba ma tọ̀; nitori ti mo gbé ọkàn mi soke si ọ.

9 JEHOFA, gbà mi lọwọ́ awọn ọtá mi : emi sá di ọ lati pa mi mọ́.

10 Kọ́ mi lati ṣe ifẹ́ rẹ; nitori iwọ li Ọlọrun mi : ẹmmí rẹ didara; fà mi lọ si ilẹ iduro ṣinṣin.

11 JEHOFA, mu mi lara ya, nitori orukọ rẹ : nitori ti ododo rẹ mu ọkàn mi jade ninu iṣẹ́.

12 Ati ni ti ãnu rẹ ke awọn ọtá mi kuro, ki o sì run gbogbo awọn ti n-ni ọkàn mi lara : nitori pe iranṣẹ rẹ li emi ṣe.

OWURỌ̀ IJỌ. 30.

PSALMU 144.

OLUBUKÚN ni JEHOFA apatta mi, ẹniti o kọ́ ọwọ́ mi li ogun, ati ika mi ni ìja :

2 Ore mi, ati odi alagbara mi; ile isọ̀ mi giga, ati olugbala mi; asà mi, ati ẹniti mo gbẹkẹle; ẹniti o tẹri awọn enia mi ba labbẹ mi.

3 JEHOFA kili enia, ti iwọ fi nkiye si i! tabi ọmmọkọnri enia, ti iwọ fi nṣe ìro rẹ!

4 Enia dabi asan : bi ojiji ti nkọja lọ li ọjọ rẹ̀.

5 JEHOFA, tẹ̀ awọn ọrun rẹ ba, ki o sì sọkalẹ : tọ́ awọn òke nla, nwọn o sì ru ẽfin.

6 Kọ manamana jade, ki o si tú wọn ká : ta ọfà rẹ, ki o sì run wọn.

7 Rán ọwọ́ rẹ lati oke wá; yọ mi, ki o sì gbà mi kuro ninu omi nla, li ọwọ́ awọn àjeji ọmmọ;

8 Ẹnu ẹniti nsọ̀rọ asan, ọwọ́ ọtún wọn sì jẹ ọwọ́ ọtún eke.

Digitized by Google

9 Ọlọrun, emi o kọn orin titun si ọ; lara èlo orin mimọ́, ati lara ohun ọnà orin olukùn mẹwa li emi o kọnrin iyìn si ọ.

10 On li o nfi ìṣẹgun fu awọn ọbba : ẹniti o gbà Dafidi iranṣẹ rẹ lọwọ́ idà pipanilara.

11 Yọ mi, ki o sì gbà mi lọwọ́ awọn àjeji ọmmọ, ẹnu ẹniti nsọ̀rọ asan, ati ọwọ́ ọtún wọn jẹ ọwọ́ ọtún eke :

12 Ki awọn ọmmọkọnri wa ki o dabi igi gbigbìn ti ndàgba lati igba ewe wọn wá; ki awọn ọmmọbiri wa ki o le dabi okuta igọn ile, ti a gbẹ bi afarawe afin :

13 Ki awọn aká wa ki o le kún, ki o ma fu-ni li onirũru iṣura : ki awọn agutan wa ki o ma bí ẹgbẹgbẹrun ati ẹgbẹgbẹrun mẹwa ni igboro wa :

14 Ki awọn malu wa ki o le rẹrù; ki o ma sì ikọlù, tabi ikolọ jade; ki o má si aroye ni igboro wa.

15 Ibukún ni fu awọn enia, ti o mbẹ ni irú ìwa bẽ : nitõtọ, ibukún ni fu awọn enia na, ti ẹniti Ọlọrun Jehofa ṣe.

Psalmu 145.

EMI o yìn ọ, Ọlọrun mi, ọbba mi; emi o sì ma fi ibukún fu orukọ rẹ lai ati lailai.

2 Li ojojumọ li emi o ma fi ibukún fu ọ; emi o sì ma yìn orukọ rẹ lai ati lailai.

3 Titobi ni Jehofa, o sì ni iyìn pupọ̀-pupọ, awa maridi ni itobi rẹ̀.

4 Iran kan yio ma yìn iṣẹ́ rẹ de ekeji, yio sì ma sọ̀rọ iṣẹ́ agbara rẹ.

5 Emi o ma sọ̀rọ iyìn ọlá-nla rẹ ti o li ogo, ati ti iṣẹ́ lyanu rẹ.

6 Enia yio sì ma sọ̀rọ agbara iṣẹ́ rẹ ti o li èru : emi o sì ma sọ̀rọ titobi rẹ.

Digitized by Google

7 Nwọn o ma sọ̀rọ iranti ore rẹ nla pupọ̀-pupọ, nwọn o sì ma kọnrin ododo rẹ.

8 Olore ọfẹ ni JEHOFA, o kún fu ãnu; o lọra lati binu, o sì li ãnu pupọ̀.

9 JEHOFA ṣeun fu awọn enia gbogbo: iyọnu rẹ̀ si mbẹ lori iṣẹ́ rẹ̀ gbogbo.

10 JEHOFA, gbogbo iṣẹ́ rẹ ni yio ma yìn ọ; awọn enia mimọ́ rẹ yio sì ma fi ibukún fu ọ.

11 Nwọn o ma sọ̀rọ ogo ti ijọba rẹ, nwọn o sì ma sọ̀rọ agbara rẹ;

12 Lati mu iṣẹ́ agbara rẹ̀ mọ̀ fu awọn ọmmọ enia, ati ọlá-nla ti ijọba rẹ̀ ti o li ogo.

13 Ijọba rẹ ijọba aiye-raiye ni, ati ijọba rẹ lati iran-diran gbogbo.

14 JEHOFA mu gbogbo awọn ti o ṣubu ró; o sì gbé gbogbo awọn ti o tẹriba dide.

15 Oju gbogbo awọn enia nwò ọ; iwọ sì fu wọn li onjẹ wọn li akokò.

16 Iwọ ṣí ọwọ́ rẹ, iwọ sì tẹ́ ifẹ́ gbogbo ohun alãye lọrùn.

17 Olododo ni JEHOFA li ọ̀na rẹ̀ gbogbo, mimọ́ sì ni iṣẹ́ rẹ̀ gbogbo.

18 JEHOFA wà letí ọdọ gbogbo awọn ti nkepè e, letí ọdọ ẹniti nkepè e ni otitọ.

19 Yio mu ifẹ́ awọn ti mbẹ̀ru rẹ ṣẹ: yio gbọ́ igbe wọn pẹlu, yio sì gbà wọn là.

20 JEHOFA da gbogbo awọn ti o fẹ ẹ si: ṣugbọn gbogbo awọn enia buburu ni yio run.

21 Ẹnu mi yio ma sọ̀rọ iyìn JEHOFA: ki gbogbo awọn enia ki o sì ma fi ibukún fu orukọ rẹ̀ mimọ́ lai ati lailai.

PSALMU 146.

EFI iyìn fu JEHOFA. Fi iyìn fu JEHOFA, iwọ ọkkàn mi.

Digitized by Google

2 Nigbati mo wà lãye li emi o ma fi iyìn fu JEHOFA : emi o ma kọnrin iyìn si Ọlọrun mi nigbati mo ni ìwa.

3 Ẹ má ṣe gbẹkẹ nyin le awọn ọmmọ-alade, tabi le ọmmọ enia, lọwọ ẹniti kò si iranlọwọ.

4 Ẹmmí rẹ jade lọ, o pada si ilẹ rẹ ; li ọjọ na gan ìro inu rẹ run.

5 Ibukún ni fu ẹniti o ni Ọlọrun Jakobu fu iranlọwọ rẹ, ireti ẹniti mbẹ lọdọ JEHOFA Ọlọrun rẹ :

6 Ẹniti o da ọrun, on aiye, okun, ati ohun gbogbo, ti o wà ninu rẹ : ẹniti o pa otitọ mọ titi aiye :

7 Ẹniti o nṣe idajọ fu ẹni inilara : ẹniti o nfi onjẹ fu ẹniti ebi npa. JEHOFA tú awọn aratubu silẹ :

8 JEHOFA ṣí oju awọn afọju : JEHOFA gbé awọn ti o tẹriba dide : JEHOFA fẹ awọn olododo :

9 JEHOFA pa awọn alejò mọ ; o tù awọn alàìni-babba ati opó lara : ṣugbọn ọna awọn enia buburu ni yio yipo.

10 JEHOFA yio jọba lailai, ani Ọlọrun rẹ, iwọ Sion, lati iran-diran gbogbo. Ẹ fi iyìn fu JEHOFA.

ALẸ IJỌ. 30.

PSALMU 147.

EFI iyìn fu JEHOFA : nitori ti o ṣe ohun rere lati ma kọnrin iyìn si Ọlọrun wa ; nitori ti o dùn, iyìn sì yẹ.

2 JEHOFA li o gbé Jerusalemu ró : on li o kó awọn ifọnkalẹ Israeli jọ.

3 O mu awọn onirora àiya lara da : o di ọgbẹ wọn :

Digitized by Google

4 O kà iye ti awọn ìrawọ; o sì pè gbogbo wọn li orukọ.
5 OLUWA wa tobi, ati alagbara nla: oyé rẹ̀ kò li opin.
6 JEHOFA gbé ọlọkkàn tutù soke: o rẹ̀ awọn enia buburu si ilẹ̀ yi ilẹ̀.
7 Ẹ fi ọpẹ́ kọnrin si JEHOFA; kọnrin iyìn si Ọlọrun wa lara dùru:
8 Ẹniti o fi awọ-sanma bò oju ọrun, ẹniti o pèse òjo fu ilẹ̀, ti o mu koriko dàgba lori awọn òke nla.
9 O fi onjẹ rẹ̀ fu ẹranko ati fu ọmmọ ìwo ti ndọn.
10 Kò ṣe inu-didùn si agbara ẹṣin: kò ṣe inu-didùn li ẹsẹ ọkọnri.
11 JEHOFA nṣe inu-didùn si awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀, si awọn ti o nṣe ireti ãnu rẹ̀.
12 Jerusalemu, iwọ yìn JEHOFA; yìn Ọlọrun rẹ̀, iwọ Sion.
13 Nitori ti o ti mu ọpá ẹnu ibode rẹ̀ le; o ti busi i fu awọn ọmmọ rẹ̀ ninu rẹ̀.
14 O ṣe alafia li àgbegbe rẹ̀, o sì fi alikama didara jù kún ọ.
15 O rán aṣẹ rẹ̀ jade wá si aiye; ọrọ rẹ̀ súre tete.
16 O fi omi didì fu-ni bi kubusu: o sì fọn ìri didì ká bi ẽru.
17 O dà didì omi rẹ̀ bi òkele: tali o le duro niwaju otutù rẹ̀?
18 O rán ọrọ rẹ̀ jade, o sì mu wọn yọ́: o mu afẹfẹ rẹ̀ fẹ, omi sì nṣàn.
19 O fi ọrọ rẹ̀ hàn fu Jakobu, aṣẹ rẹ̀ ati idajọ́ rẹ̀ fu Israeli.
20 Kò ba orilẹ̀ ède kan ṣe bẽ ri: bi o sì ṣe ti idajọ́ rẹ̀ ni, nwọn kò ti mọ̀ wọn. Ẹ fi iyìn fu JEHOFA.

Digitized by Google

Psalmu 148.

E FI iyìn fu Jehofa. Ẹ fi iyìn fu Jehofa lati awọn ọrun wá : ẹ fi iyìn fu u lati ibi giga wá.

2 Ẹ fi iyìn fu u, gbogbo ẹnyin angeli rẹ̀ : ẹ fi iyìn fu u, gbogbo ẹnyin ogun rẹ̀.

3 Ẹ fi iyìn fu u, ẹnyin õrùn ati oṣupa : ẹ fi iyìn fu u, gbogbo ẹnyin ìrawọ imọlẹ.

4 Ẹ fi iyìn fu u, ẹnyin ọrun de awọn ọrun, ati ẹnyin omi ti mbẹ loke awọn ọrun.

5 Jẹ ki nwọn ki o ma yìn orukọ Jehofa : nitori ti o paṣẹ, a sì da wọn.

6 O sì fi idi wọn mulẹ lai ati lailai : o ti paṣẹ kan ti kì yio kọja.

7 Ẹ yìn Jehofa lati aiye wá, ẹnyin erinmi, ati gbogbo ọgbọn :

8 Iná, ati yinyín ; omi didì, ati ikuku ; ẹfufu nla nmu ọ̀rọ rẹ̀ ṣẹ :

9 Awọn òke nla, ati gbogbo òke kekere ; awọn igi eleso, ati gbogbo opepe :

10 Ẹranko, ati gbogbo ẹran nla ; ohun ti nrakò, ati ẹiyẹ ti nfò :

11 Awọn ọba ti ilẹ aiye, ati gbogbo awọn enia ; awọn ọmọ-alade, ati gbogbo awọn onidajọ́ aiye :

12 Ati awọn ọmọkọnri, ati awọn ọmọbiri ; awọn enia arugbo, ati awọn ọmọde :

13 Ki nwọn ki o ma yìn orukọ Jehofa : nitori orukọ rẹ̀ nikan li o li ọlá ; ogo rẹ̀ bori aiye on ọrun.

14 O sì gbé iwo awọn enia rẹ̀ soke, iyìn gbogbo awọn enia mimọ́ rẹ̀ ; ani ti awọn ọmọ Israeli, awọn enia ti o sunmọ́ ọdọ rẹ̀. Ẹ fi iyìn fu Jehofa.

Digitized by Google

PSALMU 149.

EFI iyìn fu JEHOFA. Ẹ kọn orin titun si JEHOFA, ati iyìn rẹ̀ ninu ijọ awọn enia mimọ́.

2 Jẹ ki Israeli ki o yọ̀ si ẹniti o da a : jẹ ki awọn ọmmọ Sion ki o kún fu ayọ̀ si Ọbba wọn.

3 Jẹ ki nwọn ki o yìn orukọ rẹ̀ ninu ijó : jẹ ki nwọn ki o fi ìlu ati dùru kọnrin iyìn si i.

4 Nitori ti JEHOFA ṣe inu-didùn si awọn enia rẹ̀ : yio fi igbala ṣe awọn ọlọkkàn tutù ni li ẹwà.

5 Jẹ ki awọn enia mimọ́ ki o kún fu ayọ̀ ninu ogo; ki nwọn ki o ma kọnrin kikan lori ẹní wọn.

6 Ki iyìn giga Ọlọrun ki o wà li ẹnu wọn, ati idà oloju meji li ọwọ́ wọn;

7 Lati san ẹsan lara awọn keferi, ati ijiya lara awọn enia;

8 Lati fi ẹ̀wọn dè awọn ọbba wọn, ati lati fi ṣẹkẹ-ṣẹkẹ irin dè awọn ọlọ̀tọ wọn;

9 Lati ṣe idajọ́ si wọn lara, ti a ti kọwe rẹ̀ : ọlá yi ni gbogbo awọn enia mimọ́ rẹ̀ ni. Ẹ fi iyìn fu JEHOFA.

PSALMU 150.

EFI iyìn fu JEHOFA. Ẹ fi iyìn fu Ọlọrun ninu ibi mimọ́ rẹ̀ : yìn i ninu ofurufu oju ọrun ti agbara rẹ̀.

2 Yìn i nitori iṣẹ́ agbara rẹ̀ : yìn i gẹgẹ bi titobi rẹ̀, ti o li ọlá jù.

3 Fi ohùn ìpe yìn i : fi èlo orin mimọ́ ati dùru yìn i.

Digitized by Google

4 Fi ìlu ati ijó yìn i : fi ohun ọnà orin olokùn ati fère yìn i.
5 Ẹ yìn i lara awo idẹ olohùn oke : ẹ yìn i lara awo idẹ olokùn goro.
6 Jẹ ki ohun gbogbo ti o li ẹmmí ki o yìn JEHOFA. Ẹ fi iyìn fu JEHOFA.

Digitized by Google

ILANA WỌN-NI.

TI AFIMỌ̀ SỌKAN SI, LATI IPASE AWỌN ARCHBIṢỌPU ATI AWỌN BIṢỌPU TI IPA ỌNÀ MEJEJI ATI GBOGBO AWỌN ALUFA.

Ni Ipẹjọpọ ti ape ni Lọndọn ni Ọdun 1562, nitori ati ya kuro ninu Oniruru iyatọ Ìmọ, ati lati fi ẹsẹ Ìmọ kan lelẹ nipa otitọ Ìsin Ọlọrun. A sì tun ṣe didà rẹ̀ nipasẹ Aṣẹ Ọbba Ọlọllanla, ti on ti Ikede Ọbba to a fi si iwaju rẹ̀.

IKEDE ỌBBA ỌLỌLLANLA.

BI iti iṣe nipasẹ Ilana Ọlọrun, gẹgẹ bi Otitọ Oye wa, *Alabọ̀ Igbagbọ́ni, ati Olori Alakoso Ijọ Enia Ọlọrun, ninu Ilẹ Ọbba wa wọnyi.* Awa dì i mu pẹ o ṣe dede julọ si Oye Ọbba ti Wa yi, ati Itara ti awa niti Isìn Ọlọrun lati kojọpọ ati lati ṣe idimu Ijọ Enia Ọlọrun ti a fi le Itọju wa lọwọ́, ni Iṣọkan niti otitọ Isìn Ọlọrun ati ni Idipọ Alafia; ati ki a má ṣe jẹ ki Ija ti kò yẹ, Ijiyan, tabi ki ìbere kan ki o dide, ti yio ma bọ Iyapa, ati ninu Ijọ Enia Ọlọrun ati ninu Ilu. Njẹ nitorina lẹhin ìṣaro Ìgbimọ, ati pẹlu Ilamọran ti awọn Biṣọpu wa, iye awọn ti a lè ifi alnilara pejọ pọ̀, Awa rò pe, ọyẹ pe ki a ṣe Ikede ti o tẹ̀ le e yi.

Pe Ilana nwọn-ni ti Ijọ Enia Ọlọrun ti England (ti ati fi jì ti a sì pa li aṣẹ di isisiyi, ati ti Ẹgbẹ Aluṣa wa ima kọwe ijẹwọ si) o ni

Digitized by Google

otitọ Ẹkọ ti Ijọ enia Ọlọrun ti England ninu, o ṣe dede si Ọrọ Ọlọrun: ti Awa sì gbè lẹsẹ awa sì fi ẹsẹ rẹ̀ mulẹ. Awa mbere lọwọ́ awọn Enia Wa olufẹ, ki nwọn ki o ma duro titi ni Iṣọkan Ijẹwọ inu rẹ̀, awa sì kọ̀ iyapa kinkin kuro ninu Ilana ni na ti a ti sọ; Nitori Idi na, eyiti Awa fu nwọn li aṣẹ ki a tun u dà ni titun, ati ki a sì ro Ikede Wa yi ka pẹlu rẹ̀.

Pe Awa li Olori Akoso ti Ijọ enia Ọlọrun ti England: Ati pe bi ìyatọ ba hù niti *Ijoye* ode, nipasẹ Aṣẹ kanọn (Ila-aṣe) ati Isadilẹ miran ohunkohun ti iṣe ti inu rẹ̀. Ẹgbẹ Alufa ninu apejọpọ nwọn ni ki o làna ki o sì pari nwọn niti nwọn tete gba àmi ijẹwọ wa Gboro ni lati ṣe bẹ̃: ati ti Awa sì gbà Ilana ati Idasilẹ nwọn nwọn ni; bi ọ ba ṣepe a kì yio ṣe ọkan lọdi si Ofin ati Iṣe ti Ilẹ na yi.

Pe, lati inu Itọju nipa oye Alade wa, ki awọn Enia Ijọ Enia Ọlọrun ki o le ma ṣe Iṣẹ ti o yẹ fu awọn, Biṣọpu ati Ẹgbẹ Alufa, nigbakugba ni Ipejọpọ, nipa rirẹ lẹ Ifẹ nwọn, a o sì ma bu nwọn li aye li abbẹ Edidi Ami Wa Gboro nì lati ṣe ìṣaro, on ati ṣe iru Ohun nwọn-ni, niti nwọn ladi rẹ̀ dajudaju lati ọwọ́ nwọn wa, ti a sì fi ohun ṣọkan si lati ọdọ wa wa, ti yio ma ṣe ti ipinnu ìtoro pẹtiti, ti Ekọ ati Ilaṣẹ ti Ijọ enia Ọlọrun ti England ti a fi idi rẹ̀ mulẹ nisisiyi; kuro ninu eyiti Awa kì yio gbà ìyatọ kan tabi iyapa ni Ẹsẹ diẹ kiun.

Pe, nisisiyi na, bi atilẹ mọ́ pe nwọn ti mu ìyatọ ìwa buburu diẹ hù, ṣugbọn awa gbà itunu ninu eyi pe gbogbo awọn Alufa ninu Ilẹ Ọbba Wa niti ifẹ tifẹ inu julọ ni nwọn nkọwe ijẹwọ si Ilana ni ti A fi lelẹ: ti iṣe ifọranweran kan fu Wa pe gbogbo nwọn li o fi ohùn ṣọkan ni otitọ, bi atijọ ni ìmọ Ilana wa nipa iwe; ani ati ninu ori wọn-ni ti o ṣoro,

Digitized by Google

ninu eyiti ìyatọ̀ isisiyi gbe fara tì si, gbogbo oniruru enia li o gbà Ilana ti Ijọ enia Ọlọrun ti England ṣe ti nwọn; eyiti o sì tun ṣe afọranwe kan, pe kò si ọkan ninu nwọn ti nfẹ ṣe ikọsilẹ kan si Ilana ti a fi lelẹ.

Pe, nitorina ati ninu ìyatọ nwọn-ni ti o ṣoro laìni anfani, lati ọdun ọgọrun pupọ wa yi, ni igbakugba ati ni ibi ọ̀tọtọ, ti o dan Ijọ enia Kristi wò, Awa fẹ pe ki a fi iwadi ti o ṣoro siwaju lelẹ li apa kan, ati ki a tì ilẹku lja nwọnyi mọ́ sinu ileri Ọlọrun bi ati gbé nwọn kalẹ nigbangba fu wa ninu Iwe Mimọ Ọlọrun ati ti ìmọ gbangba ti Ilanna wọnyi ti iṣe ti Ijọ enia Ọlọrun ti England gẹgẹ bi nwọn. Ati pe bi ẹnikan lẹhin eyi ki o má ṣe dà tabi ki o má ṣe wasu, lati ma fa Ilana yi si ipa ọna kọna kan, ṣugbọn bikoṣepe ki o fi ẹsẹ le ọna rẹ̀ ninu gbangba ati ẹkọn ìmọ rẹ̀ na, ki o ma sì ṣe fi ọgbọn ti rẹ̀ tabi ihumọ̀ ti rẹ̀ ṣe itumọ̀ ti Ilana na; ṣugbọn bikoṣepe ki o gbà a ni imọ rẹ̀ bi ti iwe, ati bi ìmọ ede rẹ̀.

Pe bi Akawe ode gbangba kan, iba iṣe ninu Unifersiti (Ile Iwe Nla) iba iṣe Olori kan tabi Babba Olori Kọllege Ile Iwe Nla kan, tabi olukuluku ẹlomiran ti o wu ki o ṣe ninu ọkan ninu nwọn ti ọbba fi itumọ titún kan pẹlu Ilana kan, tabi ti nkà a ni gbangba ti o tẹnu mọ́, tabi ti o nṣe Ijiyan gbangba kan ninu Unifersiti tabi ninu Kọllege ki Kọllege tabi bi Alufa kan ninu Unifersiti ba wasu ti o sì ṣe èda ohunkohun nipa ọna kan, omiran ju eyi ti afilelẹ ni Ajọ Ipejọpọ, ti on ti Ifohunsi ti Wa bi Ọbba; on tabi awọn Ẹlẹṣẹ na yio wà ninu ewu ibinujẹ Wa ati Ègan Ijọ Enia Ọlọrun ninu Igbimọ awọn Alufa ti ayan, ati bi ẹlomiran kan bẹ̃ gẹgẹ: Awa o sì bojuto o pe ki a ṣe iṣe na ti ọyẹ si nwọn.

Digitized by Google

ÌLANA ISÌN ỌLỌRUN.

I. *Ti Igbagbọ ni Mẹtalọkan Mimọ́.*

ỌLỌRUN kanṣoṣo alàye, olõtọ ni mbẹ, aiyeraiye, laìni ara, èya ara, tabi itara; oni agbara, ọgbọn, ati ore aìlopin; Ẹlẹda ati Olupamọ ohun gbogbo ati hihàn ati alaìhàn. Ati ninu iṣọkan Ìwa-ọlọrun yi Ẹni mẹta ni mbẹ, oni ohun ìwa kan, agbara, ati ìwa aìlopin; Babba na, Ọmmọ na, ati Ẹmmí Mimọ́ na.

II. *Ti Òrọ tabi Ọmmọ, ti a da li Enia iyenia.*

ỌMMỌ na, ti iṣe Òrọ ti Babba, ti a bí lati òdọ Babba wa, lati igba ati aiyedaiye, Ọlọrun eyi Ọlọrun lailai, ati ti o ni ohun ìwa kan pẹlu Babba, o gbà ẹda enia ninu Wundia mimọ́ alabukun fu ninu ohun ìwa ara rẹ̀: Bayi ni ohun ìwa meji tòtọ ti o pe, eyini ni pe, Ohun Ìwa-ọlọrun ati Ohun Ìwa-enia dapọ ṣọkan lara Ẹni kan ni aìya kuro mọ́, nipa inu eyi ti o jasi Kristi kan Ọlọrun iyọlọrun, ati Enia iyenia; ẹniti o jìya nitotọ, ti a kan mọ́ agbelebu ti o kú ti a sì sin, lati tù Babba rẹ̀ loju fu wa, ati lati ṣe ẹbọ kan, kì iṣe ti kiki ẹṣẹ ibinibi, ṣugbọn pẹlu fu ẹṣẹ atọwọda enia.

III. *Ti Isọkalẹ Kristi lọ si Ipò okú.*

BI Kristi ti kú fu wa, ti a sì sin i, bẹ̃ ni pẹlu ki a sì gbagbọ́ pe, o sọkalẹ lọ si ipò okú.

Digitized by Google

IV. *Ti Ajinde Kristi.*

NITOTỌ ni Kristi tún jinde kuro ninu ikú, o sì tún mu ara rẹ̀, ti on ti ẹran ara, ati egungun, ati ohun gbogbo ti iṣe pipe ti ara nipa ti ẹda Enia : ti on ti eyi na yi li o goke lọ si Ọrun, o sì joko nibẹ̀, titi yio fi tún pada lati ba gbogbo Enia wijọ li opin ọjọ́.

V. *Ti Ẹmmí Mimọ́.*

EMMÍ mimọ́, ti o ntì ỳdọ Babba ati Ọmmọ wá, o ni ohun ìwa kan na, ọllanla kan, ati ogo kan na pẹlu Babba ati Ọmmọ, ti kararẹ̀ lai Ọlọrun.

VI. *Ti Titọ ti Iwe mimọ́ Ọlọrun fu Igbala.*

IWE mimọ́ Ọlọrun ni ohun gbogbo ti o yẹ fu igbala : bẽni ohunkohun ti a kò ba kà ninu rẹ̀, tabi ti a kò le itinu rẹ̀ fi ìmọ rẹ̀ hàn, ki a má ṣe bère rẹ̀ lọwọ́ ẹnikẹni, pe, ki a gbà a gbọ́ bi ìlana kan ti Igbagbọ́, tabi ki a ro o si yiyẹ tabi alaìṣaini si igbala. Ni orukọ Iwe mimọ́ Ọlọrun, awa mọ̀ wọn si Iwe ìla a ṣẹ nwọn-ni, ti Majẹmu ti Atijọ ati Titun, niti ọllá aṣẹ eyi ti kò si iyan kan ri ninu Ijọ Ọlọrun.

Ti Orukọ ati Iye Iwe ti Ìla-aṣẹ.

Genesi.	Deuteronomu.
Exodu.	Joṣua.
Levitiku.	Awọn Onidajọ.
Numeri.	Rutu.

Digitized by Google

Iwe Ekini ti Samuẹli.
Iwe Ekeji ti Samuẹli.
Iwe Ekini ti awọn Ọbba.
Iwe Ekeji ti awọn Ọbba.
Iwe Ekeni Ìtan.
Iwe Ekeji Ìtan.
Iwe Ekini ti Ẹsdra.
Iwe Ekejí ti Ẹsdra.
Iwe ti Ẹster.
Iwe ti Jobu.
Iwe ti Psalmu.
Iwe ti Owe (Proverbs).
Ekklesiaste tabi Oniwasu.
Kantika, tabi Orin Solomonu.
Iwe nlanla ti awọn Woli mẹrin.
Iwe kekeke ti awọn Woli mejila.

Ati iwe mĭ nwọn-ni (bi Hieromu ti wi) Ijọ enia Ọlọrun a ma kà wọn nitori apẹrẹ ati ẹkọ ìwa, ṣugbọn a kò fi wọn lelẹ lati fi idi ẹkọ kan le ilẹ; iru rẹ̀ ni nwọnyi:

Iwe kẹta ti Ẹsdra.
Iwe kẹrin ti Ẹsdra.
Iwe Tobia.
Iwe ti Judi.
Iwe iyoku ti Ẹster.
Iwe Ọgbọn.
Jesu Ọmmọ Siraki.
Baruki Woli.
Orin awọn Ọmmọ Mẹta ni.
Ihìn ti Susana.
Ti Bel ati ti Dragọn ni.
Adura Manasse.
Iwe Ekini ti Makkabee.
Iwe Ekeji ti Makkabee.

Gbogbo Iwe ti Majẹmu Titun, bi nwọn ti di gbigbà fu enia gbogbo, awa gbà a sì kà wọn si iwe Ìla-aṣẹ.

VII. *Ti Majẹmu Atijọ.*

MAJẸMU Atijọ kò lọdi si Titun: nitoripe ati ninu Majẹmu Atijọ, ati ninu Titun anawọ ìye alnipekun silẹ fu Araiye nipasẹ Kristi ti iṣe Onilaja nikanṣoṣo lagbedemeji

Digitized by Google

Ọlọrun ati Enia, ti on na iṣe Ọlọrun ati Enia. Njẹ nitorina, awọn wọn-ni kò ni ifi etí si ti nhumọ wipe kìki ileri igba irekoja ṣa li awọn Babba atijọ nreti. Bi atilẹ mọ pe Ofin ti a fi fu Moses lati ọdọ Ọlọrun wa, nipa ìpelo isìn ati ti isìn ironu kò dè awọn enia Kristi, bẹ̀ni Ofin ilu nwọn kò sì ṣe eyi ti iṣe alalgbọdọ ma gbà ni ilu ki ilu kan: ṣugbọn kò si Kristian kan ẹnikẹni ti o wu ki o ṣe ti o bọ lọwọ igbagbọ́ Ofin nwọn-ni ti a npè ni Ìwa-ìlo.

VIII. *Ti Igbagbọ́ Mẹ̀ẹ̀ta ni.*

IGBAGBỌ́ mẹ̀ẹ̀ta ni, ni Igbagbọ́ ti Nicene, Igbagbọ́ ti Athanasius, ati Igbagbọ́ eyi ti a ma pe ni ti awọn Apọstili, li o yẹ ti a ba ma gbà ki a sì ma gbagbọ́ li agbatan: nitoriti a le ifi ìmọ nwọn hàn ti ọ daniloju lati inu iwe mimọ́ Ọlọrun wá.

IX. *Ti Ẹṣẹ Atilẹba tabi eyi ti Abinibi.*

ÈṢẸ Atilẹba kò duro sì ti itọ Adamu lẹhin (bi awọn Pelagian ti nsọ lasan;) ṣugbọn abukun ati ibajẹ ẹda olukuluku enia ni, ti a bí lati ọdọ ọmmọ Adamu wá nipa ẹda; nipa eyiti enia fi lọ jinna rere kuro ninu ododo atilẹba, nipa ti ẹda ti ara rẹ̀, ọkkàn rẹ̀ fà si ohun ibí, bẹ̀ni ara nṣe ifẹkufẹ nigbagbogbo lodi si ẹmmí; ati nitorina ninu olukuluku enia ti a bí si aiye yi o yẹ si ijere ibinu Ọlọrun ati ère egbe. Ati èran ẹda wa yi o wà sibẹ̀, ani ninu awọn ti o di atunda; nipa eyiti ifẹkufẹ ara, ti a npe ni Phronema sarkọs, ti awọn ẹlomi mọ si ọgbọn, ẹlomi si ifẹ adùn ara, ẹlomi si ifa ọkkàn, ẹlomi si ifẹ ti ara, ti kì iforibalẹ fu Ofin Ọlọrun. Ati pe bi

Digitized by Google

o tilẹ ṣepe ẹbi kò si fu awọn ti o gbagbọ́ ti a sì baptisi, ṣugbọn Apọstili na jẹwọ pe ifẹkufẹ ara o ni ìwa ẹṣẹ ninu fu ra rẹ̀.

X. *Ti Ifẹ̀ Omnira.*

ÌWA Enia lẹhin iṣubu Adamu, o jẹ bayi pe, on kò le iyipada nipa ìwa ẹda ki o sì fi mura nipa agbara ti ontikararẹ̀, ati ti iṣe rere si igbagbọ́ ati si ikepe Ọlọrun: Njẹ nitorina awa kò ni ipa lati ṣe iṣẹ rere ati itẹwọgba sọdọ Ọlọrun, laìsi ore Ọlọrun ti nṣaju wa nipasẹ Kristi, ki awa ki o le ni ifẹ́ rere, ki o sì ma ṣiṣẹ pẹlu wa, nigbati awa ba ni ifẹ́ rere na.

XI. *Ti Idalare Enia.*

ANKÀ wa si olododo niwaju Ọlọrun, ni kìki itori itoye Jesu Kristi Olugbala wa, nipa Igbagbọ́, kì isì iṣe nipa iṣẹ rere ti awa tikarawa tabi ère titọ wa; Njẹ nitorina ti a nda wa lare nipa kìki Igbagbọ́ nikan, ọ jẹ Ẹkọ ti o yè perepereju o sì kún fu itunu, bi ati ladi rẹ̀ silẹ pupọ ninu (Homili) Iwasu ti Idalare.

XII. *Ti Iṣẹ Rere.*

BI o tilẹ ṣepe Iṣẹ Rere nwọn-ni, ti iṣe eso Igbagbọ́, ti isì ima tọ Idalare lẹhin, kò ti le mu ẹṣẹ wa kuro, ti kò sì le igba ikannu idajọ Ọlọrun duro; ṣugbọn wiwù ati titẹwọgba ni wọn fu Ọlọrun nipa Kristi, kò si tẹhin àltinu Igbagbọ́ otitọ ati yiye jade wá; to bẽ pe nipasẹ wọn li a nfi nmọ̀ Igbagbọ́ yiye dajudaju, bi ati ifi eso mọ́ igi.

Digitized by Google

XIII. *Ti Iṣẹ Kere ṣaju Idalare.*

IṢẸ ti a ṣe ṣaju ore ọfẹ ti Kristi, ati Imisi Ẹmmí rẹ̀, kò ṣe didùn mọ́ fu Ọlọrun, niwọn pe, bi nwọn kò ti ti inu igbagbọ́ ti Jesu Kristi ṣojade wá, bẹ̃ni nwọn kò sì mu enia yẹ lati gbà ore ọfẹ tabi (bi awọn Oni-Ile-iwe ti wi) kò sì yẹ si èrè eyẹ, nitotọ kàka bẹ̃ nitoriti a kò ṣe wọn bi Ọlọrun ti fẹ ti o sì fi lelẹ li aṣẹ fu wọn lati ṣe, awa kò ṣe aniani rẹ̀, nwọn sì ni ìwa ẹṣẹ.

XIV. *TI Iṣẹ Aṣele.*

IṢẸ Atinuwa pẹlu, ti o rekọja ati ti o leke, ti Ofin Ọlọrun, ti nwọn npè ni Iṣẹ Aṣele, a kò le ikọni li ẹkọ na lalni igberaga ati alnisìn: nitoripe nipa nwọn li enia nsọ pe, kì iṣe kìki eyi ti a fi le ilẹ fu wọn lati ṣe nikanṣoṣo li awọn ṣe, ṣugbọn pe awọn ṣe si i ju eyi ti abère lọ lọwọ́ wọn nipa iṣẹ isìn: Nigbati Kristi sọ dajudaju pe, Nigbati ẹnyin ba ṣe gbogbo ohun ti apalaṣe fu nyin tan, ẹ ma wipe, Ọmmọ ọ̀dọ alaìlere ni wa.

XV. *Ti Kristi nikanṣoṣo laìlẹṣẹ.*

NI otitọ ẹda wa, a da Kristi li ohun gbogbo bi awa, ẹ̀ṣẹ nikanṣoṣo li okù, ninu eyiti o mọ́ kuro to to, ati lara rẹ̀ ati li ẹmmí rẹ. O wá lati ṣe Ọdọ agutan ni lalni abawọn, ẹni, nipa ẹbọ ara rẹ̀, ti o ru lẹkan, ki o le iko ẹṣẹ nwọn-ni ti aiye lọ, bẹ̃ni, bi Saint John ti wi, pe, ẹ̀ṣẹ kò si li ara rẹ̀. Ṣugbọn gbogbo awa ara iyokun, bi o tilẹ ṣepe abaptisi wa, ti a sì tún wa bí ninu ti Kristi; ṣugbọn a ma dẹṣẹ ninu ohun pupọ; bi awa ba sì wipe

Digitized by Google

awa kò li èṣẹ, awa tan ara wa jẹ, otitọ kò sì si ninu wa.

XVI. *Ti èṣẹ lẹhin Ibaptismu.*

KÌ iṣe gbogbo èṣẹ ikú ti a mọ ọ mọ da lẹhin Ibaptismu ni iṣe èṣẹ si Ẹmmí Mímọ́, ati alaìdariji. Njẹ nitorina a kò le idu iru awọn ti o ṣubu sinu èṣẹ lẹhin Ibaptismu ni ẹbun ironupiwada. Lẹhin igbati awa ti gbà Ẹmmí Mímọ́, a le ya kuro ninu ore ọfẹ ti a fi fu ni, a sì ṣubu sinu èṣẹ, ati nipa ore ọfẹ Ọlọrun, a sì le tún dide, a sì ṣe atun hu rere ìwa. Nitorina a kò le iṣe aìdẹbi fu awọn ti nwipe, awọn kò le iṣẹ mọ́, niwọn bi awọn ti wà pẹ to nihin, tabi awọn ti ndù iru awọn ti o ronupiwada nitotọ li àye idariji.

XVII. *Ti Iyantẹlẹ ati Iyanfẹ.*

IYANTẸLẸ si Ìye, ipinnu titilai ti Ọlọrun ni nipa eyina (ṣaju ki a to fi ipilẹ aiye sọlẹ) o ti pinnu rẹ la patan nipa ìmọ rẹ ti o lumọ fu wa, lati gbà awọn ti on ti yàn nipa ti Kristi ninu awọn araiye, kuro ninu egún, ati ẹbi egbe, ati lati mu nwọn nipasẹ Kristi si igbala alànipẹkun, bi ohun èlo ti a ṣe si ọlá. Njẹ nitorina awọn ti a fi iru anfani Ọlọrun ti ọlẹwa to bayi wọ li a npè gẹgẹ bi ipinnu Ọlọrun, nipasẹ ẹmmí ti nṣiṣe nigba akokò: nipa Ore ọfẹ wọn agba ipe na gbọ́: a da nwọn lare li ọfẹ: a sọ nwọn di ọmmọ Ọlọrun nipa isọdọmmọ: a ṣe nwọn bi aworan Jesu Kristi Ọmmọ bibi rẹ nikanṣoṣo: nwọn a ma rìn ni isìn Ọlọrun ninu iṣẹ rere gbogbo, nigbatiti, nipa anu Ọlọrun, nwọn a de ibi alafia alànipẹkun.

Bi ìro iwabi ọlọrun ti Iyantẹlẹ, ati Iyanfẹ

Digitized by Google

wa nipa ti Kristi ti kún fu itunu didùn, wiwù, ati itunu ti a kò le isọ fu awọn enia iwabi. Ọlọrun, ati fu iru awọn ti o mọ ninu ara wọn, iṣiṣẹ Ẹmmí ti Kristi, ti nwọn sì npọn iṣẹ ara loju, ati ẹya ara nwọn aiye, ti nwọn sì fa ọkkàn nwọn si ohun giga ati ti ọrun nitoripe o fi ẹsẹ igbagbọ́ nwọn mulẹ ṣinṣin si ti igbala alànipẹkun ti a o fi ma jẹ alafia rẹ̀ nipasẹ Kristi, ati nitoriti o fi igbona ifẹ́ wọn hàn ni gbigbona ati nitori ti o lana si ifẹ́ wọn si Ọlọrun. Bẹ̀ni, fu awọn enia alawòfin ati enia nipa ti ara lalni Ẹmmí Kristi, lati ma gbe ipinnu aṣẹ Iyantẹlẹ Ọlọrun kalẹ niwaju wọn titi iṣubu ogedengbe ti o lewu pupọju ni, nipa eyiti Esu ntì nwọn sinu alànireti, tabi sinu ìwa oṣi ti ohun alaìmọ, kò si kere ju ewu alànireti lọ.

Pẹlupẹlu, awa kò le iṣe algba ileri Ọlọrun bẹ̀ bi iru eyi ti a gbe kalẹ fu wa ninu Iwe mimọ́ Ọlọrun; ati ni iṣe wa, Ifẹ́ Ọlọrun na ni ki a ma tọ̀ lẹhin ti a nfi nhàn fu wa dajudaju ninu Ọrọ Ọlọrun.

XVIII. *Ti ini Igbala alànipẹkun nipa Orukọ Kristi na kanṣoṣo.*

AWỌN ti a ba ma fi gegun pelu ni awọn ti o dawọ le e lati wipe, Olukuluku enia li a o gbala nipa Ofin tabi Ẹya ti o jẹwọ bi on ba sa ṣe alàsimẹlẹ lati fi ìwa aiye rẹ̀ le ilẹ gẹgẹ bi Ofin na, ati imọlẹ ìwa ẹda. Nitoripe, kìki Orukọ Jesu Kristi nikanṣoṣo ni Iwe mimọ́ Ọlọrun gbẹ́ kalẹ fu wa, nipa eyiti a o fi gbà enia là.

Digitized by Google

ÌLANA ISÌN ỌLỌRUN.

XIX. *Ti Ijọ Enia Ọlọrun.*

IJỌ Enia Kristi ti o ṣe hihàn ni Ijọ awọn olotọ enia, ninu eyiti a nwasu Ọrọ mimọ Ọlọrun, ti a sì nṣe ipinfuni Sakramenti nwọn-ni bi o ti yẹ gẹgẹ bi idasilẹ ti Kristi ninu ohun gbogbo nwọn-ni ti a kò le iṣe alaìni si eyi na. Bi Ijọ Enia Ọlọrun ti Jerusalẹmu, ti Alẹksandria ati ti Antioku ti ṣina, bẹ̀ni Ijọ Enia Ọlọrun ti Romu ṣina pẹlu, kì iṣe ni kìki ìwa nwọn ati ìwa ìlanna isìn nwọn, ṣugbọn ati ninu ọran Igbagbọ́ nwọn pẹlu.

XX. *Ti Ọlá aṣẹ ti Ijọ Enia Ọlọrun.*

IJỌ Enia Ọlọrun li agbara lati paṣẹ Isìn ironu ati ohun elo isìn, ati ọlá aṣẹ ninu Ijiyan Igbagbọ́: ṣugbọn sibẹ̀ kò tọ́ fu Ijọ Enia Ọlọrun lati da ohun kan silẹ ti o lọdi si Ọrọ Ọlọrun ti ati kọwe rẹ̀ silẹ, bẹ̀ni kò sì le ṣe itumọ̀ ibi kan ninu Iwe mimọ́ na, ti yio sì fi jà eke lyan. Njẹ nitorina, bi Ijọ Enia Ọlọrun ti iṣe ẹlẹri ati olupamọ Iwe mimọ́ ni, njẹ bi kò ti yẹ ki o fi aṣẹ ohun kan lelẹ lọdi si eyina, bẹ̀ sì ni pẹlu, eyina kò sì gbọdọ fi agbara fi ohun kan lelẹ lati gbagbọ́ li ohun alṣaini si Igbala.

XXI. *Ti Ọlá aṣẹ Ajọ Ìgbimọ Gbogbo.*

AKÒ le ipe Ajọ Ìgbimọ Gbogbo lẹhin ifẹ́ ti awọn Alade, nigbati a ba sì pe wọn jọ pọ (niwọn bi nwọn ti iṣe ajọ enia, ninu eyiti ki iṣe gbogbo wọn li a fi Ẹmmí ati Ọrọ Ọlọrun ṣe akoso) nwọn le iṣina, nigbami nwọn a sì ma ṣìna, ani ninu ohun ti iṣe ti Ọlọrun. Njẹ nitorina ohun ti a ba là silẹ

Digitized by Google

lati ọwọ́ nwọn wá pe a kò le iṣalni si ìgbala, kò li agbara tabi ọllá aṣẹ, bikoṣepe a ba fi hàn pe lati inu Ọ̀rọ mimọ́ Ọlọrun lati mu u jade wá.

XXII. *Ti Purgatori. Ibi Atubọ wẹnumọ.*

EKỌ ti awọn ara Romu nipa Ibi Atubọ wẹnumọ, Idariji, Sisìn, ati Itẹriba, ati fu ere, ati fu ẹta okú, ati pẹlu Ikepe awọn (Saint) enia Mimọ́, ohun ifẹ́ ti enia fi asan humọ̀ silẹ ni, ti kò sì ni idi nilẹ ninu iyin funi kan ninu Ọ̀rọ iwe mimọ́ ṣugbọn kàka bẹ̃ o lọ di si Ọ̀rọ Ọlọrun.

XXIII. *Ti Iṣẹ Alufa ninu Ijọ enia.*

KÒ tọ fu ẹnikẹni lati dawọ le e lati gbà oyè on iwasu li Awujọ fu ra rẹ, tabi lati ma ṣe ipinfuni Sakramẹnti nwọn-ni ninu Ijọ Enia, ki a to pè e nipa ofin ki a sì ran a lati ma ṣe eyina. Awọn nwọn-ni ti a sì ran lati ma ṣiṣẹ na yi, ẹniti a yàn ti a sì pe si iṣẹ na yi lati ọwọ́ awọn ọkọnri ni ti a fi Ọllá aṣẹ ode le lọwọ́ ninu Ijọ enia, lati pe on ati rán awọn Alufa lọ sinu Agbala Oluwa ni ki awa ki o sì ma kà si ẹni ìpe nipa ofin.

XXIV. *Ti isọrọ ninu Ijọ Enia li ède ti o ye awọn enia.*

OHUN ti o lọdi si Ọ̀rọ Ọlọrun dajudaju, ati si iṣe awọn Ijọ Enia Ọlọrun Igbani ni lati ma gbadura ninu Ijọ Enia, tabi lati ma ṣiṣẹ Ipin-funi Sakramẹnti nwọn-ni li ède ti kò ye awọn enia.

Digitized by Google

XXV. *Ti Sakramẹnti.*

SAKRAMẸNTI ti a lana silẹ lati ọwọ́ Kristi wá kì iṣe kìki àmi nikan fu ijẹwọ awọn enia ti iṣe Kristian, ṣugbọn ki nwọn ki okuku le iṣe ẹlẹri dajudaju, ati àmi ore ọfẹ ti kì itase, ati ifẹ́ inu rere Ọlọrun si wa, nipa eyi ti nṣiṣe alhan sode ninu wa, kì iṣe kìki pe nsọ wa di aye ni, ṣugbọn pẹlu ti nmu Igbagbọ́ wa lara le, ti o sì nfi ẹṣẹ rẹ̀ mulẹ ninu ara rẹ̀.

Sakramẹnti meji li a làna silẹ wa, lati ọwọ́ Kristi Oluwa wa ninu Ihin rere, eyini li anwipe, Ibaptismu, ati Onjẹ alẹ Oluwa.

Eyi marun ni ti nwọn imape ni Sakramẹnti eyini ni pe, Igbàniyanju, Iṣẹ ironupiwada, Oye Alufa, Isoyigi, ati Itorosi ni igba opin, a kò le ika nwọn si Sakramẹnti ti Ihinrere, nitoripe iru ìwa ibajẹ ti o hù lapa kan ni lati ọ̀dọ wọn wa ti o tẹle awọn Apọstle; lapa keji o jẹ ìwa aiye ti a jẹwọ fu ni ninu Iwe Ọlọrun, ṣugbọn sibẹ nwọn kò ni iru ìwa Sakramẹnti bi ti Baptismu ati Onjẹ alẹ Oluwa, nitoriti nwọn kò ni àmi hihàn kan tabi ìlana kan ti a là silẹ lati ọ̀dọ Ọlọrun wá.

Kristi kò da Sakramẹnti silẹ lati ma wò ni iran, tabi lati ma gbé kiri ṣugbọn bikoṣe pe ki a ma lò wọn bi o ti yẹ. Ati ninu iru awọn ni nikan ti ọ gbà eyina bi o ti yẹ ni nwọn ṣe aṣẹ rere; ṣugbọn awọn ti o gbà a laiyẹ, nwọn ra ẹbi egbe fu ra nwọn bi St. Paulu ti wi.

XXVI. *Ti Aìyẹ ti awọn Alufa, ti kì ida aṣeran Sakramẹnti duro.*

BI otilẹṣepe ninu Ijọ Enia Ọlọrun hihàn, ti buburu ima ba rere dàpọ titi, ati nigba-

Digitized by Google

miran ti ẹni buburu a ma ni ọllá aṣẹ ninu Ipinfuni Ọro ati Sakramẹnti nwọn-ni, ṣugbọn sibe niwọn bi nwọn kò ti ṣe eyina li Orukọ ara wọn, bikoṣe ni ti Kristi, ti nwọn sì nṣe iṣẹ Alufa nipa oye ati ọllá iṣẹ rẹ̀, a le ma gbà Iṣẹ Alufa wọn lò, ati ni gbigbọ́ Ọrọ Ọlọrun ati nigbigbà Sakramẹnti nwọn-ni.

Bẹ̃ni a kò sì gbà aranṣe ìlana ti Kristi kuro nipa iwabuburu nwọn, tabi bẹ̃ni a kò sì bu ẹbun ore ọfẹ ku kuro lọdọ iru awọn nipa igbagbọ́ ti nwọn sì gbà Sakramẹnti na bi o ti yẹ, ti a pinfu wọn lati ọwọ́ nwọn wá; eyi ti o jasi aṣẹ rere, nitoriti idasilẹ ti Kristi ati ileri rẹ̀, bi otilẹ ṣepe lati ọwọ́ awọn enia buburu lati pin wọn fu ni.

Ṣugbọn o ṣe ipa iṣẹ ti akoso ti Ijọ Enia Ọlọrun ki a bère niti awọn Alufa buburu, ki a sì fi wọn sọ̀n lati ọdọ awọn ti o mọ̀ èṣẹ nwọn wá; ati li opin rẹ̀ niti a ri wọn ninu ẹbi, nipa idajọ otitọ ki a bọ wọn li oye.

XXVII. *Ti Baptismu.*

BAPTISMU kì iṣe kìki àmi ijẹwọ ati àmi ìyatọ, nipa eyi ti ã fi imọ̀ Kristian ninu awọn ẹlomiran ti a kò sami Kristi si, ṣugbọn àmi Atunda ni pẹlu tabi ti Ibi titun, nipa eyiti, bi ẹnipe ohun èlo ti a fi nlọ awọn ti a gbà Ibaptismu nitotọ sinu Ijọ Enia Ọlọrun; ileri idariji èṣẹ, ati ti isọdọmmọ awa, lati ma ṣe ọmmọ Ọlọrun nipa Ẹmmí Mimọ́ li a ṣọ li àmi gbangba a sì de edidi rẹ̀; A fi ẹṣẹ Igbagbọ́ mulẹ, Ore ọfẹ sì npọsi i nipa agbara adura si Ọlọrun Baptismu ti awọn ọmmọ ọwọ́ ni ki a gbà si ọwọ́ ṣe ninu Ijọ Enia Ọlọrun bi o ti wù ki o ri, bi ohun ti o yẹ julọ ninu ìlana ti Kristi.

Digitized by Google

XXVIII. *Ti Onjẹ Alẹ Oluwa.*

ONJẸ alẹ Oluwa kì iṣe kìki àmi ifé ti Kristian iba ma ni ninu ara nwọn, ẹnikini si ekeji; ṣugbọn kàka bẹ̃ bikoṣe Sakramẹnti ti Idande wa nipa Ikú Kristi: to bẹ̃ pe fu iru awọn ti ọ gbà a bi o ti tọ si ati si yiyẹ, ati pẹlu igbagbọ́, Akara ti awa mbù, abapin Ara ti Kristi ni, ati pẹlu Ago Ibukún ni, alabapin Ẹjẹ ti Kristi ni.

Iparada ohun ìwa tabi ipada di ara miran ti Akara ati Ọti Wain niti Onjẹ alẹ Oluwa, ni a kò le iladi rẹ nipa Iwe mimọ́; ṣugbọn o lọdi si Iwe mimọ́ ti o daniloju: o bì iṣe idasile Sakramẹnti ṣubu, o sì da idi isìn èṣin pupọ silẹ.

A nfi ara Kristi fu ni, a ngbà a, a njẹ ẹ ninu Onjẹ alẹ na, ṣa nipa ti iṣe ọrun ati nipa ẹmmí. Ati idi nipa eyi ti a ngbà Ara Kristi ti a sì njẹ ẹ ninu Onjẹ alẹ on ni Igbagbọ́. A kò ti ọwọ́ Kristi fi ìlana Sakramẹnti Onjẹ alẹ silẹ, pe ki a ma gbà a, ki a ma gbé e kiri, ki a ma gbé e soke, tabi ki a ma fori balẹ fu u.

XXIX. *Ti enia buburu ti kò jẹ Ara Kristi ni lilo Onjẹ Alẹ Oluwa.*

ENIA buburu, ati iru awọn ti kò ni àye igbagbọ́, bi nwọn tilẹ fi ehin wọn tẹ Sakramẹnti ti Ara ati Ẹjẹ Kristi nipa ti ara ati nigbangba (bi Saint Augustine ti wi) ṣugbọn kò si ipa ti wọn gbé ṣe alabapin ti Kristi; ṣugbọn kà ka bẹ̃ nwọn jẹ, nwọn sì mu àmi tabi Sakramẹnti ti iru ohun nla ni si ẹbi egbe nwọn.

Digitized by Google

XXX. *Ti Iru mejeji.*

AKÌ ifi Ago ti Oluwa dù awọn enia alàljoye alufa: nitoripe ipa mejeji ti Sakramẹnti Oluwa li oyẹ ki a ma ṣe ipinfuni fu gbogbo enia ti iṣe Kristian bakanna, nipa ìlana ofin Kristi.

XXXI. *Ti Ọrẹ kan ti Kristi ti o pari lori Agbelebu.*

IFITỌRẸ Kristi ti o ṣe lẹkan, on ni idande, etutu, ati itẹnilọrun pipe ni, fu gbogbo ẹṣẹ agbaiye yi, ati ti alileba, ati ti atọwọda; kò sì si itẹnilọrun miran fu ẹṣẹ, bikoṣe eyina nikanṣoṣo. Njẹ nitorina ẹbọ ti Mass nwọnni ninu eyiti nwọn a fi ma wipe, Awọn Alufa nfi Kristi rubọ fu alàye ati okú, lati ni imuirora kuro tabi ẹbi ẹṣẹ o jasi ọrọ odi, jijaọrọ, ati ẹtan ti o lewu ni.

XXXII. *Ti Isoyigi ti awọn Alufa.*

AKÒ paṣẹ fu awọn Olori Alufa, awọn Alufa ati awọn Deakọni lati inu ofin Ọlọrun wa pe, ki nwọn ki o ṣe ileri iṣapọn, tabi lati mu ara duro kuro lati soyigi: nitorina, o tọ fu wọn, bi o ti tọ fu gbogbo ọkọnri Kristian lati soyigi nigbati o ba wù wọn bi nwọn ba ti rò si pe eyina yio ṣe rere si ìwabi ọlọrun.

XXXIII. *Ti awọn Ẹniti a ṣati kuro, bi a ti yà wọn silẹ.*

ENIA ni nipa ikọsilẹ gbangba ti a ṣati kuro ninu iṣọkan Ijọ Enia Ọlọrun, ti a sì yọ kuro ninu ibadapọ, o yẹ ka mu u kuro ninu

Digitized by Google

gbogbo awujọ awọn olotọ, bi Keferi ati bi Agbowode, titi digba ti yio fi ṣe itunu nipa iṣẹ ironupiwada, ti a sì gbà a sinu Ijọ Enia Ọlọrun lati ipasẹ Onidajọ wa ti o ni Ọllá a ṣẹ sinu rẹ̀ na.

XXXIV. *Ti Ìtan Ijọ Enia Ọlọrun.*

KÒ kuku ṣe agbara pe ki Ìtan ati ìlana isìn ki o ri bakanna ni ibi gbogbo ki o sì ṣe dede, nitoripe nigba gbogbo nwọn ati ma yàtọ a sì ma pa wọn da gẹgẹ bi ìyatọ ilu ilu ati igba, ati ìlo ìwa enia, niwọn bẽ ti a kò fi ṣe ìlana ohun ti o lọdì si Òrọ Ọlọrun. Ẹnikẹni nipa iro ikọkọ ara rẹ̀, ti o mọ ọ mọ̀, ti o sì pinnu rẹ̀, ti o sì ba ìtan ati ìlana isìn ti Ijọ Enia Ọlọrun jẹ, ti kò lọdi si Òrọ Ọlọrun, ti o sì ṣepe alana rẹ̀ silẹ a sì jẹwọ lati ọwọ́ Ọllá aṣẹ gbogbo otọ kulu wa, o tọ ki a ba a wi ni gbangba (ki awọn ẹlomiran ki o le ibẹru lati ṣe bẽ,) bi ẹniti o ṣẹ si ìlana Ijọ Enia Ọlọrun, ti o sì pa Ọllá aṣẹ Ijoye lara, o sì ṣa ọkkàn awọn ara alaìllera li ọgbẹ.

Olukuluku tabi ororilẹ Ijọ Enia Ọlọrun o ni ọllá aṣẹ lati da, lati parọ, ati lati ṣe iparẹ èlo isìn, isìn ironu ti Ijọ Enia Ọlọrun ti alana silẹ nipa ọllá aṣẹ enia, to niwọn bẽ ki a ṣe ohun gbogbo si igbeduro.

XXXV. *Ti Homili: Iwe Iwasu.*

IWE Iwasu (Homili) keji, orukọ olukuluku eyiti a fi tì i nisalẹ Ìlana yi, oni Ẹkọ ìwabi-ọlọrun ti o yè korokoro, o sì ṣe ohun ti a kò le iṣe aìni fu igba nwọnyi, gẹgẹ bi Iwe Homili iṣaju ti a mu jade nigba Ẹdwardi Kẹfa; nitorina awa sì rò nwọn si Kikà lati

Digitized by Google

ọwọ́ awọn Alufa wa ninu Ijọ-ijọ Enia Ọlọrun lalsimi li ohùn gbangba, ki o ye wọn ki o le iye awọn enia.

Orukọ awọn Họmili Iwe Iwasu.

1. Ti Ìlo rere Ile Ọlọrun.
2. Si ewu Iborişa.
3. Ti Itunşe ati Ipamọ Ile Ọlọrun ni mimọ́,
4. Ti Işẹ rere: şaju ti Ìgbawẹ.
5. Si Ajẹki ati Amupara.
6. Si Aşeleke ti Aşọ.
7. Ti Adura.
8. Ti Ipò ati Igba ti Adura.
9. Pe ọyẹ ki a ma şişẹ alufa ti Adura, li agbajọ ati Sakramẹnti wọn-ni li ede ti a mọ̀.
10. Ti Ibọ̀wọ fu Ọ̀rọ Ọlọrun
11. Ti Itọrẹ-anu.
12. Ti Ibí Kristi.
13. Ti Ijiya Kristi.
14. Ti Ajinde Kristi.
15. Ti Igba yiyẹ Sakramẹnti Ara ati Ẹjẹ Kristi.
16. Ti Ẹbun Ẹmmí Mimọ́.
17. Ti Ọjọ Ẹbẹ.
18. Ti Ìwa Isoyigi.
19. Ti Ironupiwada.
20. Si Ọlẹ.
21. Si Işọtẹ.

XXXVI. *Ti Iyasọtọ awọn Bişọpu ati awọn Alufa.*

IWE Iyasọtọ ti Olori awọn Bişọpu, ati ti awọn Bişọpu, ati Ifijoye awọn Alufa ati awọn Deakoni, ti a gbé lelẹ ni lọwọlọwọ yi nigba ti Ẹdwardi Kẹfa, ti a sì fi ẹsẹ eyina

Digitized by Google

mulẹ nipa ọllá aṣẹ ti Ijọ Igbimọ, o ni ohun gbogbo ninu ti o yẹ si iru Iyasọtọ ati Ifijoye bẽ̀: bẽ̀ni kò si ni ohun kan ninu, nipa ti ara rẹ̀ ti iṣe isìn-kusin tabi alaìṣe iwabi ọlọrun. Ati nitorina ẹnikẹni ti a ba yà sọtọ ti a ba sì fi joye gẹgẹ bi ìlana, bi isìn ironu ti Iwe na, lati igba Ọdun Keji Ọbba Ẹdwardi ti a ti sọ ṣaju ni di isisiyi, tabi lẹhin eyi, a o yà a sọtọ, a o sì fi joye gẹgẹ bi Ìlana na; awa pa a li aṣẹ pe gbogbo iru awọn nwọn-ni nipa titọ, lẹsẹlẹsẹ, ati bi ofin li ayasọtọ a sì fi joye.

XXXVII. *Ti awọn Ijoye Alaṣe Ilu.*

OLLANLA ti Ọbba li o ni agbara ni ilẹ Ọbba Ẹngland ati ninu Ilẹ rẹ̀ miran, ti ẹniti olori Oye Ọbba Ilẹ iṣe, iba iṣe ti Iṣẹ Alufa tabi ti Ijoye ilu, ninu ohun gbogbo ti rẹ̀ ni; ki isì iṣe, tabi kò sì yẹ, lati ṣe, ki o sì tẹriba fu ajeji Ilẹ Ọbba.

Nibiti awa fi olori ijọbba fu Ọllanla ijọbba, nipa Orukọ na, li eyiti awa fi nmọ̀ inu awọn kan, ewu enia, pe a kàn wọn le ewọ̀ awa kò fi iṣiṣe Alufa ti Ọrọ Ọlọrun tabi ti Sakramẹnti fu awọn Alade wa, ohun na yi, ti Aṣẹ ti a pa ni lọwọlọwọ yi, lati ọwọ́ Elisabẹti Ọbba wa, o fi hàn ni gbangba; ṣugbọn kìki aṣẹ ni ti awa ri ti a ti nfi fu gbogbo awọn Alade ẹni ìwabi-ọlọrun ninu Iwe mimọ́ lati ọwọ́ Ọlọrun tikara rẹ̀ wá; eyini ni pe, ki nwọn ki o ma ṣe akoso ìwa gbogbo ati ila gbogbo ti a fi si sakani iṣọ wọn, iba iṣe Ijoye Alufa, tabi ti Ijoye aiye, ki o sì fi idà oye alaṣẹ ilu ṣe akoso awọn agidi ati awọn olusẹ buburu enia.

Olori alufa ti Romu kò ni ilẹ ni Ilẹ Ọbba Ẹngland yi.

Digitized by Google

IFẸSẸLELẸ.

Ofin Ilẹ Ọbba le ifi ikú ṣẹ awọn enia Kristian ni iṣẹ, nitori èṣẹ ati iwa buburu.

Otọ fu awọn ọkọnri Kristian nipa ofin awọn Ijoye ilu lati di ihamọra ogun, on ati sìn li ogun.

XXXVIII. *Ti ohun ini ti Kristian ti kì iṣe Ajọni.*

ỌRỌ ati Ohun ini ti Kristian ti kì iṣe Ajọni nipa itosi nipa orukọ, ati nipa ini eyina, bi awọn kan Aṣodisi baptisti ti nṣefefe eke. Ṣugbọn bi o ti ri bẽ ni gbogbo enia li ọyẹ, ninu iru ohun ti o ni, ki o ṣe ọṣọnnu ki o mu ṣe itọrẹ anu fu talaka, niwọn bi agbara rẹ ti to.

XXXIX. *Ti Èpe Enia ti iṣe Kristian.*

BI awa ti jẹwọ pe, a kọ Ibura asan ati ti alrotẹlẹ fu awọn Enìa ti iṣe Kristian lati ọwọ Oluwa wa, Jesu Kristi wá, ati Jakọbu Apọstili rẹ, bẽli awa rò pe Isìn Kristi kò kọ funi pe, ki a má ṣe bura nigbati awọn Ijoye ilu ba bère rẹ, ninu ọran ti igbagbọ, ati ti ifẹni, niwọn bẽ bi a ba ṣe e gẹgẹ bi Ẹkọ Woli ni, li alṣegbe ni idajọ ati li otitọ.

IFẸSẸLELẸ.

IWE Ìlana yi ti a ti kà ṣaju ni, a sì tún jẹwọ rẹ, awa sì fẹ ẹ lati dimu, ati lati ṣe e ni Ilẹ Ọbba yi nipa ijẹwọ ati Ifohun si Iyalode, Elisabẹti Ọbba wa, nipa ore ọfẹ Ọlọrun, ti England, France, ati Ireland Ọbba Alabò Igbagbọ ni &c. Iwe Ìlana na yi ni a kà

Digitized by Google

pẹlẹpẹlẹ, ti a sì tún fi ẹsẹ rẹ lelẹ nipa ikọwe ijẹrisi lati ọwọ́ awọn Archbiṣọpu ati awọn Biṣọpu ti Ile Igbimọ Oke ni, ati nipa ikọwe ijẹrisi lati ọwọ́ awọn gbogbo Alufa ti Ile Igbimọ̀ Isalẹ ni ninu Apejọpọ wọn li Ọdun Oluwa wa 1571.

ORUKỌ ÌLANA NWỌN-NI.

1. Ti Ìgbagbọ́ ni Mẹtalọkan Mimọ́.
2. Ti Ọ̀rọ tabi Ọmmọ ti a da li enia iyenia.
3. Ti Iṣọ kalẹ Kristi lọ si Ipo okú.
4. Ti Ajinde Kristi.
5. Ti Ẹmmí Mimọ́.
6. Ti Titọ ti Iwe mimọ́ Ọlọrun fu Igbala.
7. Ti Majẹmu Atijọ.
8. Ti Ìgbagbọ́ Mẹtẹta ni.
9. Ti Ẹ̀ṣẹ Atilẹba tabi eyiti Abinibi.
10. Ti Ifẹ́ Omnira.
11. Ti Idalare.
12. Ti Iṣẹ Rere.
13. Ti Iṣẹ Rere ṣaju Idalare.
14. Ti Iṣẹ Aṣẹle.
15. Ti Kristi nikanṣoṣo lalẹ̀ṣẹ.
16. Ti Ẹ̀ṣẹ lẹhin Baptismu.
17. Ti Iyantẹlẹ ati Iyanfẹ.
18. Ti ẹni Igbala alnipẹkun nipa Orukọ Kristi nikanṣoṣo.
19. Ti Ijọ Enia Ọlọrun.
20. Ti Ọ̀làá aṣẹ ti Ijọ Enia Ọlọrun.
21. Ti Ọ̀làá aṣẹ Ajọ Ìgbimọ Gbogbo.
22. Ti Purgatory Ibi Atubọ wẹ̀numọ.
23. Ti iṣẹ Alufa ninu Ijọ Enia.
24. Ti isọrọ ninu Ijọ Enia li ede ti o ye awọn enia.

Digitized by Google

IWE AJỌBI ATI IBATAN.

25. Ti Sakramẹnti.
26. Ti Aìyẹ ti awọn Alufa ti kì ida aṣeran Sakramẹnti duro.
27. Ti Baptismu.
28. Ti Onjẹ Alẹ Oluwa.
29. Ti awọn Enia buburu ti kò jẹ Ara Kristi ni lilò Onjẹ Alẹ Oluwa.
30. Ti Iru mejeji.
31. Ti Ọrẹ kan ti Kristi ti ọ pari lori Agbelebu.
32. Ti Isoyigi ti awọn Alufa.
33. Ti awọn Ẹniti a ṣati kuro, bi a ti yà wọn silẹ.
34. Ti Ìtan Ijọ Enia Ọlọrun.
35. Ti Họmili: Iwe Iwasu.
36. Ti Iyasọtọ awọn Biṣọpu ati awọn Alufa.
37. Ti awọn Alaṣẹ Ilu.
38. Ti ọhun ini ti Kristian ti kì iṣe Ajọni.
39. Ti Èpe Enia ti iṣe Kristian.

IWE AJỌBI ATI IBATAN.

NINU EYITI BI ẸNIKẸNI BA TAN A KỌ FU U NINU IWE MIMỌ ỌLỌRUN ATI NINU OFIN WA LATI NI ARA WỌN LI ỌKỌ ATI LI AYA.

Ọkọnri ki o má ṣe ni ì li aya—

1. Iyala rẹ.
2. Aya babba la rẹ.
3. Iyala aya rẹ.
4. Arabiri Babba rẹ.
5. Arabiri Iya rẹ.
6. Aya Arakọnri Babba rẹ.
7. Aya Arakọnri Iya rẹ.

Digitized by Google

8. Arabiri Babba Aya rẹ.
9. Arabiri Iya Aya rẹ.
10. Iya rẹ.
11. Aya Babba rẹ.
12. Iya Aya rẹ.
13. Ọmmọbiri rẹ.
14. Ọmmọbiri Aya rẹ.
15. Aya Ọmmọbiri rẹ.
16. Arabiri rẹ.
17. Arabiri Aya rẹ.
18. Aya Arakọnri rẹ.
19. Ọmmọbiri ti Ọmmọkọnri rẹ.
20. Ọmmọbiri ti Ọmmọbiri rẹ.
21. Aya Ọmmọkọnri ti Ọmmọkọnri rẹ.
22. Aya Ọmmọkọnri ti Ọmmọbiri rẹ.
23. Ọmmọbiri ti Ọmmọkọnri Aya rẹ.
24. Ọmmọbiri ti Ọmmọbiri Aya rẹ.
25. Ọmmọbiri ti Arakọnri rẹ.
26. Ọmmọbiri ti Arabiri rẹ.
27. Aya Ọmmọkọnri ti Arakọnri rẹ.
28. Aya Ọmmọkọnri ti Arabiri rẹ.
29. Ọmmọbiri ti Arakọnri Aya rẹ.
30. Ọmmọbiri ti Arabiri Aya rẹ.

Obiri ki o má ṣe ni i li ọkọ—

1. Babba la rẹ.
2. Ọkọ Iyala rẹ.
3. Babba la Ọkọ rẹ.
4. Arakọnri Babba rẹ.
5. Arakọnri Iya rẹ.
6. Ọkọ Arabiri Babba rẹ.
7. Ọkọ Arabiri Iya rẹ.
8. Arakọnri Babba Ọkọ rẹ.
9. Arakọnri Iya Ọkọ rẹ.
10. Babba rẹ.
11. Ọkọ Iya rẹ.

Digitized by Google

12. Babba Ọkọ rẹ̀.
13. Ọmmọkọnri rẹ̀.
14. Ọmmọkọnri Ọkọ rẹ̀.
15. Ọkọ Ọmmọbiri rẹ̀.
16. Arakọnri rẹ̀.
17. Arakọnri Ọkọ rẹ̀.
18. Ọkọ Arabiri rẹ̀.
19. Ọmmọkọnri ti Ọmmọkọnri rẹ̀.
20. Ọmmọkọnri ti Ọmmọbiri rẹ̀.
21. Ọkọ Ọmmọbiri ti Ọmmọkọnri rẹ̀.
22. Ọkọ Ọmmọbiri ti Ọmmọbiri rẹ̀.
23. Ọmmọkọnri ti Ọmmọkọnri Ọkọ rẹ̀.
24. Ọmmọkọnri ti Ọmmọbiri Ọkọ rẹ̀.
25. Ọmmọkọnri ti Arakọnri rẹ̀.
26. Ọmmọkọnri ti Arabiri rẹ̀.
27. Ọkọ Ọmmọbiri ti Arakọnri rẹ̀.
28. Ọkọ Ọmmọbiri ti Arabiri rẹ̀.
29. Ọmmọkọnri ti Arakọnri Ọkọ rẹ̀.
30. Ọmmọkọnri ti Arabiri Ọkọ rẹ̀.

Digitized by Google